COURSE GUIDE

# YOR 215
# ÌFÁÁRÀ SÍ LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ
# (INTRODUCTION TO YORÙBÁ ORAL LITERATURE)

**Course Team** Ojogbon Philip Adédọ̀tun Ògúndèjì *FNAL* (Òǹkọ̀wé Kọ̀ọ́sì) – UI Ibadan
Ọ̀jọ̀gbọ́n Adeṣọlá Ọlátẹ́jú Olóòtú Kọ́ọ̀sì)

NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA

© 2023 by NOUN Press
National Open University of Nigeria
Headquarters
University Village
Plot 91, Cadastral Zone
Nnamdi Azikiwe Expressway
Jabi, Abuja

Lagos Office
14/16 Ahmadu Bello Way
Victoria Island, Lagos

e-mail: centralinfo@nou.edu.ng
URL: www.nou.edu.ng

All rights reserved. No part of this book may be reproduced, in any form or by any means, without permission in writing from the publisher.

Printed 2023

ISBN: 978-978-058-886-1

**CONTENT** **PAGE**


Course Description………………………………………………. iv
Ìfáárà Sí Kọ́ọ̀sì Yìí…………………………………………….. iv
Èròǹgbà Àti Àfojúsùn Kọ́ọ̀sì Yí…………………………… v
Ojúṣe Akẹ́kọ̀ọ́……………………………………………… v
Ìgbélewọ̀n Akẹ́kọ̀ọ́……………………………………… vi
Ìdánwò Àṣekágbá………………………………………….. vi
Ìlànà Máàkì Gbígbà………………………………………... vii

## COURSE DESCRIPTION

The course deals with the scope of of oral literrature in Yorùbá: its oral and written nature; problems involved in the collection transcription and classification of oral literature, folktales, traditional poetic and dramatic forms.

Kọ́ọ̀sì yìí wà fún àgbéyẹ̀wò tìbú-tòòró lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá: ìjẹmálohùn rẹ̀ àti àkọsílẹ̀ rẹ̀; àwọn ìṣoro tí ó rọ̀ mọ́ ṣiṣàkójọ, ṣíṣàdàkọ àti pínpín sísọ̀rí-ìsọ̀rí lítíréṣọ̀ alohùn, àwọn àlọ́ onítàn, ewì àbáláyé àti eré oníṣe àbáláyé.

## ÌFÁÁRÀ SÍ KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ

Kọ́ọ̀sì yìí ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ gbogbo kọ́ọ̀sì lítíréṣọ̀ Yorùbá yòókù nítorí pé òun ni ó dúró bí i ìpalẹ̀mọ́ fún gbogbo iṣẹ́ lítíréṣọ̀ Yorùbá yòókù. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun tí o ó kọ́ nínú kọ́ọ̀sì náà ni yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ nínú àwọn kọ́ọ̀sìtí o ó ṣì ṣe ni àwọn ìpele ẹ̀kọ́ rẹ ní ọjọ́ iwájú. Kódà kì í ṣe ẹ̀kọ́ lítíréṣọ̀ alohùn nìkan ni yóò wúlò fún àti ti àpilẹ̀kọ pàápàá, pẹ̀lú tìṣọwọ́lò-èdè tí o je ọ̀kan nínú àwọn kọ́ọ̀sì àìgbọdọ̀-máṣe nínú ìkẹ́kọ̀ọ́-gboyè rẹ. Yúnítì mẹ́ta (3 Units) sì ni. Nítorí náà, mo gbà ọ́ níyànjú gidigidi pé kí o múra sí i dáradára. Mo gbìyànjú níwọ̀n bí àyè ṣe gbà mí tó láti ṣàlàyé àwọn ẹ̀kọ́ náà lọ́nà tí yóò gbà tètè yé ọ pẹ̀lú àpẹẹrẹ kíkún tí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́.

Módù mẹ́ta ni a pín gbogbo iṣẹ́ náà sí. Ìpín márùn-ún márùn-ún ni ó wà nínú módù kọ̀ọ̀kan. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan sì ni ìpín kọ̀ọ̀kan náà.Èyí túmọ̀ sí wí pé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ mẹ́ẹ̀dógún ni gbogbo àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ́ọ̀sì yìí. Abala mẹ́ta ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan ní; Ìbẹ̀rẹ̀, Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìIparí. Abala ìbẹ̀rẹ̀ ni ìfáàrà (1.0), èròǹgbà àti àfojúsùn (2.0) pẹ̀lú ìbéèrè ìṣájù (3.0) wà, kí ó tó kan ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gan-an gan (4.0). A gbìyànjú láti pín ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà sí ẹ̀ka kéékèké láti jẹ́ kí o lè máa lọ láti ìgbésẹ̀ kan dé ìkejì àti ní ẹsẹ ẹsẹ. Ní abalá ìparí ni Ìsọníṣókí àti àgbálọgbábọ̀ (5.0), Iṣẹ́ àmúṣe (6.0) àti Ìwé ìtọ́kasí (7.0) wà. Ìlànà ètò yìí wà láti mú ìkẹ́kọ̀ọ́ dẹrùn fún ọ.

Bí o bá fẹ́ gbádùn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú kọ̀ọ́sì yìí dáradára, tí o sì ni àfojúsùn láti ṣe àṣeyege àti àṣeyọrí tí ó mọ́yán lórí, ó di dandan kí o ṣe àwárí àwọn àpẹẹrẹ tara tìrẹ, yàtọ̀ sí àwọn èyí tí èmi, gẹ́gẹ́ bí olùdánilẹ́kkọ̀ọ́ rẹ ti ṣe fún ọ nínú àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inu kọ́ọ̀sì náà. Nípa kíka àwọn Ìwé ìtọ́kasí (àti fún kíkà síwájú sí i) tí a kó jọ sí ìparí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan àti àwọn ìwé mìíràn, bẹ́ẹ̀ tí ìwọ náà tún ṣe àwárí, ni ó ṣe lè ṣe eléyìí. Nítorí wí pé alohùn ni lítiréṣọ̀ tí à ń gbé yẹ̀wò jẹ́, tí ó sì jẹ́ pé wọ́n ṣì ń lò ó ní àwùjọ tìtí di òní, yóò dára bí o bá tún ṣe ìwádìí lọ́dọ̀ àwọn tí wọ́n nímọ̀ nípa àṣà ìbílẹ̀ àwùjọ Yorùbá ní àyíka rẹ lórí àwọn lítíréṣọ̀ náà. O sì tún lè wo ìtàkùn àgbáyé àti pàápàá 'You Tube' àti 'Face Book' fún àpẹẹrẹ oríṣiríṣi àwọn lítíréṣọ̀ náà síwájú sí i. Gbogbo èyí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ púpọ̀ púpọ̀, yóò sì tún mú kí ìmọ̀ rẹ jinlẹ̀ sí i. Àbèèrè ọnà ni kì í ṣáà ṣìnà. Ìmọ̀ràn míràn tí

mo tún ní fún ọ ni pé kí o rí i dájú pé o kó ara rẹ níjàánu láti máa ka àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà déédéé kí o sì máa ṣe gbogbo àwọn iṣẹ́ àmúṣe tí a yàn fún ọ ní àsìkò. Má fi òní dá ọla, kí ó má báà yọ sílẹ̀ lẹ́yìnọ̀rẹyìn; kí ó má sì wá já sí àbámọ̀ fun ọ. Ààbọ̀ ọ̀rọ̀, ó tó fún ọmọlúwàbí o. Àṣeyè tí alákàn n ṣepo ni o ó ṣe kọ́ọ̀sì yí àti àwọn yòókù náà o. Múra o!
Ire!

## ÈRÒŃGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN KỌ́Ọ̀SÌ YÍ

Nígbà tí o bá ka gbogbo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ́ọ̀sì yí parí, oóò ti lè ṣe ìdámọ̀ àwọn oríṣiríṣi lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, o ó sì ti lè fi ìdánílójú jíròrò nípa ọ̀gangan ipò wọn, pẹ̀lú àwọn àbùdá ètò ìhun àti tìṣeré wọn.

Láti mú kí èròǹgbà yí kẹ́sẹjárí, a ṣe àlàyé kíkún nípa àwọn ìṣoro tàbí ìpèníjà tí ń kójú akẹ́kọ̀ọ́ lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá àti bí ó ṣe lè bórí wọn. A lo àpẹẹrẹ tó péyé láti ṣe àgbéyẹ̀wò ìpínsísọ̀rí àti àtúnpínsísọ̀rí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. A jíròrò lórí ọ̀gangan ipò àwọn ewì alohùn Yorùbá, àlọ́ onítàn àti eré oníṣe. A sì ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbúdá ìṣeré, ìhun, àkóónú àti ìmúlò èdè wọn.

## OJÚṢE AKẸ́KỌ̀Ọ́

Àwọn ojúṣe rẹ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ kọ́ọ̀sì yí nìwọ̀nyí:

1. Dáhùn àwọn ìbéèrè ìṣaájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan kí ó tó bẹ̀rẹ̀ sí í ká ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà. Èyí wà láti ràn ọ́ lọ́wọ́ kí ó lè mọ àwọn nǹkan tuntun tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ kọ́ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí o ba kà á tán.

2. Ka àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú ìwé kọ́ọ̀sì yí ní àkàyé.

3. Wá àwọn àpẹẹrẹ mìíràn tí ó bá ohun tí o kà mu dáadáa. Èyí ni yóò jẹ́ ìdánilójú pé àwọn ohun tí o kà yé ọ dáradára. Nípa kíka àwọn ìwé mìíràn àti ṣíṣe ìwádìí síwájú sí i láwùjọ ni ó ṣe lè ṣe èyí. O ó rìí àpẹẹrẹ àkọlé àwọn ìwé mìíràn tí ó lè kà sí i ní àbẹ́ 'Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí' (7.0)

4. Dáhùn àwọn ìbéèrè ìkẹyìn tí ó wà lábẹ́ àkọlé Ìṣẹ́ àmúṣe. Èyí ni yóò dúró bí ìgbéléwọ̀n fún àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó ti kà ní opin kọ́ọ̀sì náà.

5. Rí i dájú pé o fi ìdáhùn rẹ ṣọwọ́ sí olùdánilẹ́kọ̀ọ́ tàbí ibi tí ó yẹ ni àkókò ìfẹnukò-sí. Èyí ṣe pàtàkì nítorí ìjìyà lè wà fún ẹni tí kò bá fi tirẹ̀ ṣọwọ́ ní àsìkò tí ó yẹ.

6. Bí ó bá nílò ìrànlọ́wọ́ kan tàbí òmíràn, má lọ́ra láti kàn sí olùdánilẹ́kọ̀ọ́ tàbí àwọn aláṣẹ gẹ́gẹ́ bí ó bá ti yẹ. Abèèrè ọ̀nà ni, kì í ṣìnà.

7. Ní ìparí, o nílò àwọn ìwé èdè ìperí méjì ti a kọ àkọlé wọn sísàlẹ̀ wọ̀nyí; kì í ṣe fún kọ́ọ̀sì yí nìkan, bí kò ṣe gbogbo ẹ̀kọ́ àkàgboyè rẹ nínú èdè, àṣà, lítíréṣọ̀ àti ìkọ́ni Yorùbá.

Bámgbóṣé, Ayọ̀ 1984. *Yorùbá Metalanguage (Èdè-Ìperí Yorùbá)Fol. I*, tí Nigerian Educational Reaserch and Development Council kọ́kọ́ gbé jáde ni 1984, UPLC, Ìbàdàn tún gbé jáde fún NERDC àti Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá, 1992, 2004.

Awobùlúyì Ọládélé 1990 *Yorùbá Metalanguage (Èdè-Ìperí Yorùbá)Fol. II*, tí UPLC, Ìbàdàn gbé jáde fún NERDC àti Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá,

## ÌGBÉLEWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan ni ó ní àwọn ìbéèrè ní ìparí wọn tí wọ́n ní àkọlé 'Ìṣẹ́ Àmúṣe tí Olùkọ́ yóò Máàkì.' Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ márùn-ún ni modù kọ̀ọ̀kan ní, a jẹ́ pé irú ìbéèrè bẹ́ẹ̀ márùn-ùn ni ó wà fún módù tàbí táàmù kọ̀ọ̀kan. Mo gbà ọ́ ní ìyànjú kí ó dáhùngbogbo àwọn ìbéèrè ìnú kọ́ọ̀sì náà pátápátá. Mẹ́ta tí ó bá ti ṣe dáadáa jù lọ nínú márùn-ún ni à óò fi ṣe ìgbéléwọ̀n bí o ṣe ṣe dáradára sí nínú iṣẹ́ módù kọ̀ọ̀kan. Lẹ́ẹ̀kan sí i, rí i dájú pé o fi ìdáhùn rẹ ṣọwọ́ sí olùdánilẹ́kọ̀ọ́ tàbí àwọn aláṣẹ gẹ́gẹ́bí ó ti tọ́.

## ÌDÁNWÒ ÀṢEKÁGBÁ

Ó pọn dandan láti ka gbogbo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú kọ́ọ̀sì yí. Gbobo àwọn ìṣọ̀ríìsọ̀rí rẹ̀ ni ìbéèrè yóò ti jáde nínú ìdánwò. Gẹ́gẹ́ bí a sì ti sọ tẹ́lẹ̀, ìdá àádọ́rin nínú ọgọ́rùn-ún (70%) máàkì ni a óò gbé gbogbo ìdánwò ìparí kọ́ọ̀sì náà lé. Ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún (30%) yòókù ni yóò jẹ́ ìgbéléwọ̀n àwọn iṣẹ́ inú kọ́ọ̀sì náà tí a fún ọ. Láti gbáradì fún ìdánwò, yóò dára bí ó bá ṣe àtúngbéyẹ̀wò àwọn ìbéèrè iṣẹ́ àmúṣe dáadáa, àwọn ìsọníṣókí àti àgbálọgbábọ̀ pẹ̀lú àwọn àkọsílẹ̀ tí o ti ṣe fúnra rẹ. Ìwọ̀nyí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ púpọ̀púpọ̀. Mo gbà ọ́ ní ìyànjú pé kí o ka ìbéèrè dáadáa kí o tó dáhùn rẹ̀ ní àkókó ìdánwò, kí osì fi iyè sí àwọn ọ̀rọ̀ ìtọ́sọ́nà àti àkíyèsí orí ìwé ìbéèrè ìdánwò náà dáradára pẹ̀lú. Mo tún gbà ọ́ níyànjú pé kí o lo àwọn àpẹẹrẹ tí o ṣàwárí fúnra rẹ ju èyí tí olùkọ́ fún ọ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lọ. Èyí ni yóò fi hàn gbangba wí pé ohun ti o kà yé ọ yékéyéké, pé kì í kàn ṣe pé àkọsórí ni o fi gbogbo ìkẹ́kọ̀ọ́ náà ṣe, tí ó o sì fi rí máàkì tí ó rú gọ́gọ́ gbà.

## ÌLÀNÀ MÁÀKÌ GBÍGBÀ

Ìlànà máàkì fún kọ́ọ̀sì yí:

| | | |
|---|---|---|
| Ìgbéléwọ̀n mẹ́ta mẹ́ta fún módù kọ̀ọ̀kan (máàkì mẹ́wàá fún ìkọ̀ọ̀kan) 10 x 3 | = | Máàkì 30% |
| Ìdánwò ní ìparí kọ́ọ̀sì | | Máàkì 70% |
| Àropọ̀ gbogbo máàkì | | 100% |

**MAIN COURSE**

**(ÀKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ) CONTENT** **PAGE**


| | | |
|---|---|---|
| **Módù 1** | **Ìfáàrà Gbogbogbòò…………………………** | **1** |
| Ìpín 1 | Kín ni Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá jẹ́?............... | 1 |
| Ìpín 2 | Ìpèníjà Ẹ̀kọ́ Lítíréṣọ̀ Alohùn I: Oko Ìwádìí Lílọ………………………………………….. | 9 |
| Ìpín 3 | Ìpèníjà Ẹ̀kọ́ Lítíréṣọ̀ Alohùn II:Àbọ̀ Oko Ìwádìí………………………………………… | 16 |
| Ìpín 4 | Ìpínsísọ̀rí Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá I: Àwọn Isọ̀rí Ǹláǹlá………………………………... | 23 |
| Ìpín 5 | Ìpínsísọ̀rí Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá II: Àwọn Ìsọ̀rí Kéékèèké………………………… | 32 |
| **Módù 2** | **Ewì Àlohùn…………………………………...** | **42** |
| Ìpín 1 | Àrángbọ́ Kíkún……………………………….. | 42 |
| Ìpín 2 | Àrángbọ́ Kéékèèké…………………………… | 59 |
| Ìpín 3 | Ìṣàré Ajẹmẹ́sìn……………………………….. | 74 |
| Ìpín 4 | Ìṣàré Aláìjẹmẹ́sìn…………………………….. | 98 |
| Ìpín 5 | Orin…………………………………………… | 107 |
| **Módù 3** | **Àlọ́ Onítàn Àti Eré Oníṣe……………………** | **127** |
| Ìpín 1 | Àlọ́ Pípa àti Àtúnyẹ̀wò Ìpínsísọ̀rí Àlọ́ Onítàn.. | 127 |
| Ìpín 2 | Kókó Ọ̀rọ̀, Àhunpọ̀ Ìtàn, Ibùdó àti Àkókò Ìtàn…………………………………………… | 139 |
| Ìpín 3 | Ẹ̀dá Ìtàn, Ìfiwàwẹ̀dá àti Ìlò Èdè……………… | 158 |
| Ìpín 4 | Ọdún Ìbílẹ̀…………………………………… | 173 |
| Ìpín 5 | Eégún Aláré………………………………….. | 186 |

# MÓDÙ 1 ÌFÁÁRÀ GBOGBOGBÒÒ

Ìpín 1 Kín ni Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá jẹ́?
Ìpín 2 Ìpèníjà Ẹ̀kọ́ Lítíréṣọ̀ Alohùn I: Oko Ìwádìí Lílọ
Ìpín 3 Ìpèníjà Ẹ̀kọ́ Lítíréṣọ̀ Alohùn II:Àbọ̀ Oko Ìwádìí
Ìpín 4 Ìpínsísọ̀rí Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá I: Àwọn Isọ̀rí Ǹláńlá
Ìpín 5 Ìpínsísọ̀rí Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá II: Àwọn Ìsọ̀rí Kéékèèké

## IPIN 1 KÍN NI LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ JẸ́?

### ÀKÓÓNÚ

1.0 Ìfáárà

2.0 Èròǹgbà Àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ìtumọ̀ Lítíréṣọ̀ Gẹ́gẹ́ bí Ẹyọ Ọ̀rọ̀
4.2 Àríyànjiyàn Lórí Ìlò Lítíréṣọ̀ Alohùn bí Èdè Ìperí
4.3 Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá Gẹ́gẹ́bíi Lítíréṣọ̀ Adáyébá, Ajẹmáwùjọ, tó Wà fún Gbogbogbòò
4.4 Àfiwé lítíréṣọ̀ Alohùn àti Àpilẹ̀kọ

5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Àwọn òyìnbó láti Yúróòpù tí wọ́n kọ́kọ́ ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú Áfíríkà kò gbà ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ pé àwọn ènìyàn dúdú ní lítíréṣọ̀, èrò ìjìnlẹ̀, ẹ̀sìn àti àwọn ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ mìíràn. Ṣùgbọ́n àwọn ọmọ bíbí ilẹ̀ Áfíríkà ti wọ́n kàwé ti ṣe iṣẹ́ takuntaku láti fi hàn pé eléyìí kò rí bẹ́ẹ̀. Lára èso oríṣìíríṣìí iṣẹ́ tí wọ́n ti ṣe ni ó fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ danindain pé kò sí bí igúnnugún ṣe se orí tí ìnàkí kò ṣe. Ohun tí ó wá hàn gbangba ni wí pé gbogbo èdè àti àṣà ni ó ní lítíréṣọ̀ tirẹ̀. Àǹfàní ìdàgbàsókè tí àwọn èdè kan ní, tí ó jẹ́ pé wọn ti ní àkọsílẹ̀ fún ọdún pípẹ́ ti àwọn kan kò sì ní irú àǹfàní bẹ́ẹ̀ ni ó ṣe atọ́nà fún irú ìrònú àwọn ará Yúróòpù tí a mẹ́nu bà yẹn. Ní tiwọn, lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ nìkan ni wọ́n kà sí lítíréṣọ̀. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé èdè sísọ ṣàgbà kíkọ sílẹ̀, inú èdè sísọ ni orísun lítíréṣọ̀ àṣà kan máa ń wà. Ohùn ẹnu sì ni a fi máa ń ṣàgbékalẹ̀ irú lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Bí lítíréṣọ̀ Yorùbá

náà sì ti jẹ́ nìyẹn. Lára àwọn àgbà onímọ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá tí wọ́n ti ṣe iṣẹ́ takuntakun kan tàbí òmíràn nípa lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, tí a ó sì bá pàdé nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni Adébóyè Babalọlá, Ayọ̀ Bámgbóṣe, Ọládélé Awóbùluyì, Wándé Abímbọ́lá, Ọlátúndé Ọlátúnjí, Akínwùmí Ìṣọ̀lá, Afọlábí Ọlábímtan, Olúwọlé Olúkòjú, Olúdáre Ọlájubù, Olúgbóyèga Àlàbá, Oyin Ògúnbà, Joel Adédèjì, Ọmọ́táyọ̀ Olútóyè, Bádé Àjùwọ̀n, Babátúndé Ògúnpòlù, Túnjí Ọ̀pádọ̀tun,Bádé Àjàyí, Délé Orímóògùnjẹ́, Mákanjúọlá Ilésanmí, Láidé Sheba àti Adédọ̀tun Ògúndèjì, Adéṣọlá Ọlátẹ́jú, Ayọ̀ Ọ̀pẹ̀fèyítìmí, Ṣọlá Ajíbádé, Bọ̀dé Agbájé,Sulaiman Rájí, Ayọ̀ọláAránsí, Ayọ̀ Fáséhùnabbl. Àwọn wọ̀nyí àti akin ẹlẹgbẹ́ wọn mìíràn ti fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé Yorùbá ní lítíréṣọ̀, ṣaájú kí àṣà ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà tó dé. Lítíréṣọ̀ alohùn tí a tún mọ̀ sí 'àtẹnudẹ́nu' sì ni lítíréṣọ̀ náà.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín kìn-ín-ní yìí, o ó ti lè ṣàlàyé ohun tí lítíréṣọ̀ alohùn jẹ́. O ó ti lè sọ̀rọ̀ nípa àwọn àríyànjiyàn tí ó wà lórí ìlò lítíréṣọ̀ alohùn gẹ́gẹ́ bí orúkọ tàbí èdè ìperí àti díẹ̀ nínú àwọn orúkọ mìíràn tí àwọn kan dá lábàá kí á máa pè é. O ó sì lè ṣe àlàyé lórí bí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ṣe jẹ́ àdáyébá àti ti gbogbogbòò tàbí mùtúmùwà. O óò tún ti lè sọ díẹ̀ lára àwọn ìjọra àti ìyàtọ̀ tó wà láàrin lítíréṣọ̀ alohùn àti lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ. Eyí ni yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ nínú akitiyan ìṣèdámọ̀ lítíréṣọ̀ alohùn dáadaa.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ní ṣókí, kín ni Lítíréṣọ̀ alohun Yorùbá?
2. Dárúkọ àwọn onímọ̀ Yorùbá márùn-ún tí wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.
3. Àwọn wo ni kò gbà pé ó tọ̀nà láti máa sọ ọ̀rọ̀ lítíréṣọ̀ alohùn, kín sì ni ìdí tí wọn kò fi gbà bẹ́ẹ̀?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìtumọ̀ Lítíréṣọ̀ Gẹ́gẹ́ bí Ẹyọ Ọ̀rọ̀

Kò sí àní-àní wí pé láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì ni a ti yá lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀ wọ inú èdè Yorùbá. Láti inú èdè Látìn, tí ó jẹ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì ti ṣẹ̀ sì ni ọ̀rọ̀ náà ti wọ inú èdè Gẹ̀ẹ́sì gan-an alára ní bí i sẹ́ntíúrì kẹ̀rìnlá. Láti inú *literatura/ litteratura* (èyí tí a kọ sílẹ̀), tí ó jẹ jáde láti inú *littera* (lẹ́tà – *letter*) (www.scribd.com, Ìlésanmí 2004) ni ìpìlẹ̀ ọ̀rọ̀ yìí. Gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹyọ yìí, ìtumọ̀ ìpìlẹ̀ fún lítíréṣọ̀ ni 'àkọsílẹ̀.' Èyí ni pé, gbogbo ohun tí a bá kọ sórí ìwé tàbí tí a tẹ̀ jáde nínú ìwé ni lítíréṣọ̀ túmọ̀ sí láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Títí di àkókò yìí, ìtumọ̀ náà ṣì ń jẹ́ mímúlò nínú èdè Gẹ̀ẹ́sì nítorí wí pé gbogbo awọn àkọsílẹ̀ tí ó bá jẹ mọ́ ìmọ̀ tàbí ẹ̀kọ́ kan ni wọ́n máa ń pè ní lítíréṣọ̀ ẹ̀kọ́ tàbí ìmọ̀ náà. Ìdí nìyẹn, nínú èdè Gẹ̀ẹ́sì, tí a fi lè sọ̀rọ̀

*Religious literature* (lítíréṣọ̀ ìmọ̀ Ẹ̀sìn), *Mathematical literature* (lítíréṣọ̀ ìmọ̀ Mátimátíìkì), , *Historical literature* (lítíréṣọ̀ ìmọ̀ ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi, *Political literture* (lítíréṣọ̀ ìmọ̀ Ìṣèlú) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ṣùgbọ́n lóde òní, ìtumọ̀ lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ọnà tí a fi èdè gbé kalẹ̀ ti di àkànlò àmúlò èdè láàyè ara rẹ̀. Ìtumọ̀ àkànlò yìí kò fúnka mọ́ ọ̀rọ̀ kíkọ sílẹ̀ nìkan gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀. Ó fi àyè sílẹ̀ fún kíka àmúlò èdè sísọ lẹnu kún lítíréṣọ̀. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé bí a ti lè sọ̀rọ̀ lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ náà ni a lè sọ̀rọ̀ ti alohùn tàbí àpilẹ̀ṣọ.

## 4.2 Àríyànjiyàn Lórí Ìlò Lítíréṣọ̀ Alohùn Bí Èdè Ìperí

Nítorí ìtumọ̀ ìpìlẹ̀ tí lítíréṣọ̀ ní yìí ni àwọn onímọ̀ kan, pàápàá àwọn tí wọ́n jẹ́ ọmọ ilẹ̀ Yúróòpù àti àwọn ọmọ ìlẹ̀ Afiríkà kọ̀ọ̀kan tí wọ́n fara mọ́ èrò wọn, kò ṣe gbà wí pé ó tọ̀nà láti máa sọ ọ̀rọ̀ lítíréṣọ̀ alohùn. Ní èrò tiwọn, bí ẹni ń sọ ojú ọ̀rọ̀ àti òdì ọ̀rọ̀ kan náà papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà ni èyí já sí. Pọ́n-ọ́n-na ńlá sì ni ó jọ lójú wọn (Ilésanmi 2004). Ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí a ti sọ àti bí ó ṣe jẹyọ nínú àlàyé tí a ti ṣe lókè, ìtumọ̀ ẹyọ ọ̀rọ̀ kan amáa yí padà lẹ́yìn ọjọ́ pípẹ́; tí ó jẹ́ pé àmúlò rẹ̀ yóò yàtọ̀ sí bí ó ṣe wà nigbà kan rí. Ohun tí ó ṣẹlẹ̀ ni pé *literature* nínú èdè Gẹ̀ẹ́sì gan-an ti ní ìtumọ̀ méjì báyìí. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ti ṣe, ìtumọ̀ àkọ́kọ́ ni ti àkọsílẹ̀ láti inú èdè Látìn, tí Gẹ̀ẹ́sì ti jẹ jáde, ìkejì sì ni iṣẹ́ ọnà èdè. Ìtumọ̀ kejì yìí ni ó fi àyè sílẹ̀ fún wa láti sọ̀rọ̀ lítíréṣọ̀ alohùn gẹ́gẹ́ bí àlàyé wa ìṣaájú. (wo Kennth Rexroth, Literature, nínú Brittanica Online Encylopedia britannica.com) Àwọn onímọ̀ kan ti dábàá pé kí á yàgò pátápátá fún àmúlò àwọn ọ̀rọ̀ onípọ́n-ọ́n-na yìí. Díẹ̀ lára àbá tí àwọn onímọ̀ wọ̀nyí ti dá kí á máa lò dípò lítíréṣọ̀ alohùn ni ọ́réṣọ̀ (*orature*),ọ́rálíṣọ̀ (*oraliture*), ọnà ohùn ẹnu (*verbal/oral art*). fókìlọ̀ọ̀ (folklore/ folkart), ọnà mùtúmùwà/ gbogbogbòò(popular art), ìṣeré (performance) abbl. (Wo Finnegan,1970àti Ilésanmí (2004) fún àlàyé síwájú sí i lórí oríṣìíríṣìí orúkọ mìíràn tí àwọn onímọ̀ ti lò dípò lítèrèṣọ̀ alohùn).

Ìsúnkì *oral* àti *literature* ni *orature* (ọ́réṣọ̀) àti oraliture (ọralíṣọ̀). Kò sí ìyàtọ̀ nínú ìtumọ̀ àkànpọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ méjèèjì náà lẹ́yìn ìsúnkì àti ṣaájú ìsúnkì. Ìdúnnumọ́ jíjẹ́ ọnà ni àmúlò ọnà ẹnu fòté lé. Ìtumọ̀ fókìlọ̀ọ̀ ní tirẹ̀ ń fòté lé e wí pé àwọn ọnà náà jẹ́ ti abínibí àwọn ènìyàn ìbílẹ̀ kan. Ohun kan tí a tún kíyèsí ni pé kì í ṣe ọnà ohùn nìkan ni a máa ń lo fókìlọ̀ọ̀ fún. Gbogbo ohun tí ó jẹ mọ́ àṣà àti ìṣe àwọn ènìyàn ìbílẹ̀ kan ni ìtumọ̀ rẹ̀ kó sínu fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ onímọ̀, pàápàá ti àwùjọ àwọn ènìyàn tí kò ní ìmọ̀-ọ́nkọ-mọ̀-ọ́nkà. Ṣùgbọ́n àwọn kọ̀ọ̀kan a máa lò ó fún ọnà ohùn/ẹnu nìkan (Finnegan, 1970). Ìtumọ̀ abẹ́nú kan wà tí fókìlọ̀ọ̀ dàbí ẹni tún ní bí a ti pe àkíyèsí sí. Èyí ni ti ìpààlà láàrin àwọn tí wọ́n gbà pé àwọn lítíréṣọ̀ tiwọn ni ó dára jù àti àwọn ẹ̀yà ìbílẹ̀ tí tiwọn kò dára tó. Ìtumọ̀ ìdẹ́yẹsí kan náà yìí tí ó ti wà láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ náà ni ó ṣì ń ń fara hàn nínú àmúlò fókìlọ̀ọ̀ àti ọ̀rọ̀ ìpérí mìíràn bíi *ethnopoetics* àti *ethnic literature*. Lóòtọ́ ni pé lítíréṣọ̀ alohùn jẹ́ ọnà mùtúmùwà tàbí gbogbogbòò ní àwùjọ ṣùgbọn àwọn ohun èlò àti ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ òdè òní, lákòókò bágbàmu yìí, ti mú kí

jíjẹ́ ti gbogbogbòò kẹnú ju ti ìbánisọ̀rọ̀ olojúkojú lọ. Níwọ̀n ìgbà tí àwọn lítíréṣọ̀ alohùn wọ̀nyí náà ti di mímúlò lórí àwọn ẹrọ ìbánisọ̀rọ̀ òde òní náà, a lérò pé ìṣàmúlò orúkọ yìí náà wúlò. Ìṣeré (performance) tí àwọn kan sì pe àwọn ọnà ẹnu wọ̀nyí náà kò burú nítorí ṣíṣe ni gbogbo wọn níwọ̀n ìgbà tí wọn ti jẹ́ àpilẹ̀ṣọ, tí wọn kì í ṣe àpilẹ̀kọ.

Nínú kọ́ọ̀sì yìí, èdè ìperí tí àwa yàn láàyò ni lítíréṣọ̀ alohùn (oral literature). Yàtọ̀ sí àwọn ìdí tí a ti fẹsẹ̀ wọn múlẹ̀, ìdí tí a fi yàn án láàyò ni pé a fẹ́ kí ó yéni yékéyéké wí pé ọnà ohùn ẹnu Yorùbá àti ti ilẹ̀ Afíríkà yòókù lápapọ̀ lè figagbága pẹ̀lú lítíréṣọ̀ níbikíbí lágbàáyé.

## 4.3 Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá Gẹ́gẹ́ bíi Lítíréṣọ̀ Àdáyébá, Ajẹmáwùjọ, tó wà fún Gbogbogbòò

Pàtàkì ni àṣà ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà nínú oríṣiríṣi àwọn àṣà àtọ̀húnrìnwá tí wọ́n bá ẹ̀sìn Mùsùlùmí àti ti Ọmọlẹ́yìn Jésù wásọ́dọ̀ àwa Yorùbá. Àṣà yí ni ó ní í ṣe pẹ̀lú lítíréṣọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú ojúwòye àwọn àtọ̀húnrìnwá náà. Àìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà àwọn ìran Yorùbá àti ilẹ̀ Áfíríkà lápapọ̀ ni ó jẹ́ kí lára àwọn àtọ̀húnrìnwá náà lérò pé a kò ní lítíréṣọ̀, àròjinlẹ̀, ìmọ̀ ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi abbl. Irú ojúwoye yìí kù káàtó tóÌṣọwọ́kọ̀wé ti Lárúbáwá tí a tún mọ̀ sí Áájàmí ni àwọn àgbà àfáà Mùsùlùmi ti kọ́kọ́ fi ń kọ èdè Yorùbá ṣaájú kí àwọn ajíyìnrere ọmọlẹ́yìn Jésù àti ìjọba Gẹ̀ẹ́sì tó tún kó ìṣọwọ́kọ̀wé ti ìlànà Róòmù dé tí wọn sì fi ń kọ Yorùbá bákan náà. Ṣùgbọ́n kí àgbàdo tó ó dáyé, ó níhun tí adìẹ kúkú ń jẹ. Ṣaájú fifi àṣà ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà ní ìlànà ìṣọwọ́kọ̀wé méjèèjì yìí kọ èdè Yorùbá ni àwọn babańlá ìran Yorùbá ti ní àwọn ọnà ẹnu àti ìṣeré lóríṣiríṣi, tí wọn fi ń gbé èrò ìjìnlẹ̀ kalẹ̀ tí wọ́n fi ń dára wọn lára ya, tí wọ́n sì fi ń sàmì àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ pàtàkìpàtàkì ní ìgbésí ayé wọn. Ìdí nìyítí a fi rí i gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ àbáláyé. Ìyẹn ni pé àwọn lítírè ṣọ̀ àpilẹ̀ṣọ ti wà ṣaájú àṣàìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé láti ìgbà ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ àwọn baba ńlá wa (ní bíi ààrín 2000 sí 1000 ṣaájú ikú Olúwa wa), bóyá ṣaájú kí Odùdùwà tilẹ̀ tó dìdelẹ̀tàbí kí ó tó dé sáàrin àwọn Yorùbá (ní bíi 1000 Lẹ́yìn ikú Olúwa wa(Wo Àtàndá 2007, fún àwọn déètì yìí)ni púpọ̀ nínú àwọn ọnà ẹnu àti ìṣeré wọn ti wà.

Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé ara àṣà ni lítíréṣọ̀ wà, tí ó sì jẹ́ pé dídàgbà ni àṣà tí kò bá ní í kú máa ń dàgbà sí i, lítíréṣọ̀ náà gbọ́dọ̀ máa bá àṣà dàgbà ni. Ohun tí èyí ń tọ́ká sí ni pé, a kò lè ṣàìrí lára àwọn lítíréṣọ̀ alohùn náà tí ó dìdelẹ̀ ní àkókò kan tàbí òmíràn ní pàtó. A sọ eléyìí láti fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn Yorùbá ni olùṣẹ̀dá àwọn lítíréṣọ̀ náà, àwọn Yorùbá sì ni olùgbọ́ tàbí aṣàmúlò rẹ̀ àkọ́kọ́, bẹ́ẹ̀ ni kò sí ànì-aní wí pé lórí àṣà àti ìrírí láwùjọ Yorùbá ni wọ́n gbé àwọn ọnà ohùn àti tìṣeré wọn kà, tàbí tí wọ́ dá lé.

Ohun kan tí a gbọ́dọ̀ tún mẹ́nu bà ni pé lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ alohùn yòókù ní àgbáyé, kì í ṣe ti àwọn ọlọ́lá tàbí bọ̀rọ̀kìnní nìkan. Bí ọ̀pọ̀ àwọn lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ti wà fun àwọn ọlọ́lá tàbí

bọ̀rọ̀kìnní náà ni wọ́n wà fún mẹ̀kúnnù. Gbogbo ènìyàn láwùjọ ló lè ṣe àmúlò èyí tí ó bá tọ́ sí wọn. Gẹ́gẹ́ bí a óò ti máa rí i nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó ṣe é ṣe kí irúfẹ́ lítíréṣọ̀ alohùn kan jẹ mọ́ obìnrin ju ọkùnrin lọ, tàbí kí òmíràn jẹ mọ́ ọmọdé ju àgbà lọ. A sì le rí èyí tí ó pa tọmọdétàgbà, tọkùnrintobìnrin pọ̀. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé lítíréṣọ̀ tí ó jẹ mọ́ ìgbésí ènìyàn láwùjọ típẹ́típẹ́ ni. A máa ń bá a pàdé nínú oríṣìíríṣìíṣe láwùjọ gẹ́gẹ́ bíi ẹ̀sìn, ìṣèlú, òwò àṣejèrè, iṣẹ́ ọwọ́, orò ṣíṣe, ìdárayá àti ayẹyẹ, ẹ̀kọ́ abbbl.

## 4.4 Àfiwé Lítíréṣọ̀ Alohùn àti Àpilẹ̀kọ

Láti jẹ́ kí ṣíṣe ìdámọ̀ lítíréṣọ̀ alohùn rọrùn ni a ṣe fẹ́ fi wé tàpilẹ̀kọ ní ìhín. A ó kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ nípa ìjọra wọn ná, kí á tó sọ̀rọ̀ àìjọra wọn.

**Ìjọra:**

- Ohun àkọ́kọ́ tí ó pa àwọn lítíréṣọ̀ alohùn àti tàpilẹ̀kọ Yorùbá pọ̀ ni péàwọn ọmọbíbí ilẹ̀ Yorùbá ni olùṣẹ̀dá méjèèjì,
- Ọ̀rọ̀ nípa ìrírí láwùjọ Yorùbá sì ni kókó ọ̀rọ̀ àkóónú àwọn litíréṣọ̀ méjèèjì. Èdè Yorùbá kan náà ni àwọn lítíréṣọ̀ méjèèjì sì máa ń ṣàmúlò.
- Àwọn àbúdá ẹwà èdè Yorùbá kan náà ni àwọn lítíréṣọ̀ méjèèjì máa ń mú lò. Lára àwọn ọnà èdè (*figures of speech*)tí ó ń fara hàn nínú lítíréṣọ̀ alohùn àti tàpilẹ̀kọ ni àfiwe tààrà àti tẹlẹ́lọ̀ọ́, ìfohunpèèyàn, àfidipò, ọ̀rọ̀ àpẹ́sọ,ẹ̀dà ọ̀rọ̀, ẹ̀gọ́, ìyánrọ̀ fẹ́rẹ́, àsọdùn,ìfọ̀rọ̀dárà, àkàwé abbl. Lára àwọn ọnà ìró (*figures of sound*) tí àwọn méjèèjì máa ń lò niìrósínròójẹ/idíófóònù fìrósínròójẹ, idíófóònù fìrómọ̀rísí, àwítúnwí fáwẹ́lì, àwítúnwí kọ́ńsónáǹtì, ìfìró-ohùn-takóra, ìfìró-ohùn-gbera abbl.
- Bákan náà ni oríṣìíríṣìí àwọn ọnà ìṣọwọ́lò èdè (*stylistic features*) bíi ìbádọ́gbagbólóhùn, àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀ tàbí ìfọ̀rọ̀gbe-ọ̀rọ̀, àwítúnwí ẹyọọ̀rọ̀, àwítúnwí odindigbólóhùn, àwítúnwí alákùdégbólóhùn abbl.

**Àìjọra:**

- Ìyàtọ̀ pàtàkì tí ó pààlà gbòógì sáàrin àwọn oríṣìí lítíréṣọ̀ méjèèjì ni ti pé ìlànà gbígbé jáde pẹ̀lú ohùn ẹnu ni a fi ṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ alohùn, ṣùgbọ́n ti kíkọ sílẹ̀ sínú ìwé ni a fi sẹ̀dá lítíréṣọ̀ àpìlẹ̀kọ. Ìdí nìyí tí a fi pè é ní àpilẹ̀kọ tí a sì tún lè pe lítirèṣọ̀ alohùn, tí a fi ohùn ẹnu gbe kalẹ̀ láti ìpìlẹ̀ ní àpìlẹ̀sọ. Ohùn ẹnu tàbí ọ̀rọ̀ sísọ ni wọ́n fi ṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ alohùn, ohùn náà ni wọ́n máa fi ń gbé e kalẹ̀ lójú agbo eré tabí ibi ìṣeré, bákàn náà ló jẹ́ pé ohùn ẹnu náà ni à ń lò láti fi ìmọ̀-ọ̀nṣe rẹ̀ kọ́ni. Nípasẹ̀ ohùn ẹnu ni lítíréṣọ̀ alohùn tún máa fi ń tàn káàkiri láti agbègbè kan dé èkejì tí wọ́n sì máa ń filé ìran tí ń bọ̀ lọ́wọ́. Ìdí nìyí tí a fi ń pè é ní lítíréṣọ̀ àtẹnudẹ́nu ṣaájú

kí a tó fẹnu kò sí lítíréṣọ̀ alohùn gẹ́gẹ́ bí èdè ìperí. Lórí ìyàtọ̀ yí ni púpọ̀ àwọn ìyàtọ̀ yòókù rọ̀ mọ́.

- Inú ìwé tí a kọ lítíréṣọ̀ àpìlẹ̀kọ sí ni ibùdó àkọ́kọ́ rẹ̀. Bí a bá gbé e kalẹ̀ níbi ìṣeré, ibúdó rẹ̀ onípò-kejì ni ibi ìṣeré tí a ti gbé e kalẹ̀ yẹn yóò jẹ́. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé àpilẹ̀ṣọni lítíréṣọ̀ alohùn, ojú agbo eré, tí ó jẹ́ ibi ìṣeré rẹ̀ náà ni ibùdó rẹ̀ àkọ́kọ́. Bí a bá wá ṣe ìdàkọ lítíréṣọ̀ alohùn sínú ìwé, èyí kò sọ ọ́ di àpilẹ̀kọ, lítíréṣọ̀ alohùn tí a dà kọ ni ìyẹn, tàbí kí á kúkú sọ pé lítíréṣọ̀ àdàkọ. Ibùdó onípòkejì ni inú ìwé tí a da lítíréṣọ̀ alohùn kọ sí yóó wá jẹ́ fún un nígbà náà.
- Àkókò ìṣẹ̀dá (*composition*) àti ìṣeré (*performance*) lè papọ̀ nínú lítíréṣọ̀ alohùn. Ìyẹn ni pé lójú agbo eré níbi tí onílítíréṣọ̀ alóhùn (b. a. apohùn/ àpàlọ́/ aṣesínjẹ tàbí òṣèré) ti ń ṣe ìgbékalẹ̀ iṣẹ́ ọnà rẹ̀, ó lè ṣẹ̀dá nǹkan tuntun tí kò sí nínú ọnà rẹ̀ tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀. Kì í kàn ṣe pé àkọ́sórí ohun tí ó ti kọ́ ni ó ń gbé kalẹ̀. Àkókò ìṣẹ̀dá àti ìṣeré kì í papọ̀ rárá rárá nínú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọní tirẹ̀. Lẹ́yìn ti òǹkọ̀wé bá kọ̀wé tán ni a tó lè kà á, ní àkàgbádùn tàbí kí á ṣe é lórí ìtàgé tí ó bá jẹ́ eré onítàn àpilẹ̀kọ. Mo fẹ́ kí á kíyèsí i ní ìhín wí pé àkókò ìṣeré ni kíka ìtàn àrosọ àti ewì já sí. Ṣíṣe ètò àyọkà àwọn ìwé ìtàn àròsọ ní orí rédíò ló wá jẹ́ kí èyí hàn ketekete lóde òní.
- Nítorí kíkọ sílẹ̀ tí a kọ lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ sílẹ̀ láti ilẹ̀ wá, a máa ń sábàá mọ olùṣẹ̀dá rẹ̀. Olùṣẹ̀dá yóò ti kọ orúkọ ara rẹ̀ sí ara ìwé lítíréṣọ̀ náà. A kì í sábàá mọ olùṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ alohùn nítorí àpilẹ̀sọ tí ó jẹ́. Èyí ni ó jẹ́ kí ó dàbí ẹni pé lítíréṣọ̀ alohùn kò ní olùṣẹ̀dá kan pàtó, pé àwùjọ ni ó ni in. Lílò fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún ní í máa mú kí á gbàgbé ẹni tí ó kọ́kọ́ gbé e kalẹ̀.
- Ètò pàtó, tí ó gún régé máa ń wà nínú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ; ìṣupọ̀ a sì máa wà láàrin àwọn ìsọ̀rí ìsọ̀rí inú rẹ̀. Èyí kò pọn dandan nínú lítíréṣọ̀ alohùn rárá. Òhun tí ó tilẹ̀ wọ́ pọ̀ ni wí pé kí àyàbá wà nínú àgbékalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn, nígbà míràn òṣèré sì tilẹ̀ má rántí láti padà sórí ọ̀rọ̀ tí ó ń bá bọ̀ ṣaájú àyàbánáà.Èyí kì í jẹ́ kí ìṣùpọ̀ tí ó gún régé ó wà nínú ìhun lítíréṣọ̀ alohùn.
- Ohun tí ó tún wọ́pọ̀ nínú lítíréṣọ̀ alohùn tí kì í sì í tó nǹkan nínú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ ni àwítúnwí. Bí a bá da lítíréṣọ̀ alohùn tí ó ní àwítúnwí kọ sínú ìwé, adùn rẹ̀ kò lè má ṣàìsọnù. Ojú agbo eré, ní ibi ìṣeré ni adùn rẹ̀ ti lè hàn gbangba.
- Má-yà-mí ni lítíréṣọ̀ alohùn àti ọ̀gangan ipò rẹ̀. Ìyẹn ni pé ibi tí a ti ń lò ó ni ojúlówó àyè tí ẹwà rẹ̀ ti le bú yọ jùlọ. Nígbàkúgbà tí a bá gbé ìṣeré lítíréṣọ̀ alohùn kúrò ní ọ̀gangan ipò rẹ̀, a tí sọ ọ́ di ajá inú ìwé ti kò lè gbó àti ẹṣin inú ìwé tí kò lè ta. Ògidì adùn àti ìwúlò rẹ̀ ni a ti yọ kúrò yẹn. Eréfèé ni gbogbo nǹkan tó kù. Ọ̀gangan ipò àti ìwúlò lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ kò wọnú ara wọn típẹ́típẹ́ bí i ti lítíréṣọ̀ alohùn.
- Síwájú sí i, ìlànà ìkọ́ṣẹ́/ìkọ́ni pàtó a máa wà fún ọ̀pọ̀ lítíréṣọ̀ alohùn, pàápàá ewì; kì í sì í sábà á sí fún lítireṣọ̀ àpilẹ̀kọ. Ẹni tí

yóò bá kọ ohùn pípè tàbí orin àlùjó kan gbọ́dọ̀ lọ kọ́ṣẹ́ lábẹ́ ọ̀gá kan. Ṣùgbọ́n ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà ni ó pọn dandan fún ẹni tí ó bá fẹ́ máa kọ lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ. Ìrírí nípa iṣẹ́ àwọn aṣaájú àti ọgbọ́n àtinúdá ara tirẹ̀ ni yóò máa wá mú lò.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ohun tí a fẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ nínú ìpín kìn-ín-ní módù yìí ni pé a lè lo 'lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá' gẹ́gẹ́ bí èdè ìperí fún ṣíṣàpèjúwe àkópọ̀ àwọn ọnà ẹnu abínibí àwọn Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ, kò sí bí ọ̀bọ ṣe ṣe orí tí ìnàkí kò ṣe ni. Lára ìdí tí a fi yan orúkọ yìí láàyò ni pé, yàtọ̀ sí pé ó bá kọ́ọ̀sì wa mu, ó tún fi ìgbàgbọ́ wa hàn wí pé àwọn bàba ńlá wa kì í ṣe òpè; kì í ṣe àwọn kan tí ó ti ọ̀nà jìnjìn wá ni ó wá kọ́ wọn ní lítíréṣọ̀. Ṣaájú kí ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà tó dé, kí lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ tó dìdelẹ̀ ni ọnà ẹnu Yorùbá ti wà. Kì í ṣe àwọn Yorùbá nìkan ni èyí rí bẹ́ẹ̀ fún ṣá ó. Gbogbo èdè àti àṣà jákèjádò àgbáyé ni ó ní lítíréṣọ̀ alohùn tàbí ọnà ẹnu ti wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a yan lítíréṣọ̀ alohùn láàyò gẹ́gẹ́ bí èdè ìperí nínú kọ́ọ̀sì yìí, èyí kò di wa lọ́wọ́ láti lo àwọn orúkọ yòókù, pàápàá tí wọn kò bá ti ní ìtumọ̀ ìtàbùkù tàbí ìdẹ́yẹ-sí.

- Nínú akitiyan wa láti jẹ́ kí á mọ ohun tí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá jẹ́ ní ìpín kìn-ín-ní módù yìí, a kọ́kọ́ ṣe àgbéyẹ̀wò ìtumọ̀ méjì tí lítíréṣọ̀ ní lóde òní; ìyẹn ni àkọsílẹ̀ àti ọnà àfèdè-gbé-kalẹ̀. Ìtumọ̀ kejì yí ni a sọ pé ó fi àyè sílẹ̀ fún ìmúlò lítíréṣọ̀ alohùn bí èdè ìperí.
- A tẹ̀ síwàjú lórí ọ̀rọ̀ yìí láti wo àwọn orúkọ mìíràn bíi ọnà ẹnu, ọ́rẹ́ṣọ̀, fókìlọ̀ọ̀, ọnà mùtúmùwà/gbogbogbòò àti ìṣeré.
- A kò ṣàìtọ́ka sí àwọn àbùdá pàtàkì lítíréṣọ̀ mẹ́ta kan tí ó ṣe kókó, ìkínní ni pé àbáláyé ni, ìyẹn ni pé ó ti wà ṣaájú àṣà ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà, yálà ní ìlànà Ájàmí(tàwọn Lárúbáwá) tàbí ti Róòmù (tí àwọn Gẹ̀ẹ́sì kọ́kọ́ kó dé nípasẹ̀ ẹ̀sìn ọmọlẹ́yìn Jésù); ìkejì ni pé lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, gẹ́gẹ́ bíi ti àwọn orílẹ̀ èdè yókù, lágbàáyé jẹ mọ́ àwùjọ tipẹ́típẹ́. Kò ṣe é yà kúrò nínú àṣà àti ìṣe àwùjọ Yorùbá. Ìkẹta ni pé lítíréṣọ̀ tí ó wà fún gbogbo èniyàn láwùjọ ni.
- Láti jẹ́ kí a wá mọ ohun tí lítíréṣọ̀ alohùn jẹ́ dáradára a ṣe àfiwé rẹ̀ pẹ̀lú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ. Ọ̀nà mẹ́rin tí a sọ pé wọn fi jọra ni pé èdè Yorùbá kan náà ni wọ́n ń lò, nípa àṣa àti ìrírí láwùjọ Yorùbá ni wọ́n sì máa ń dá lé, nítorí náà àkóónú wọn a máa jọra, àwọn ọmọ abínibí Yorùbá ní wọ́n sì máa ń jẹ́ olùṣẹ̀dá àti olùgbọ́ wọn ìpìlẹ̀.
- Ìsọ̀rí ńlá ńlá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ti lítíréṣọ̀ máa ń ni kárí ayé (ewì, ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere àti eré oníṣe) ni àwọn méjèèjì sì ní.
- Ọ̀nà mẹ́jọ, tí a tọ́ka sí pé àwọn lítíréṣọ̀ méjèèjì fi yàtọ̀ ni ti pé: lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ jẹ́ oníkíkọ-sílẹ̀ láti ilẹ̀ wá ti alohùn sì jẹ́ onísísọ-lẹ́nu; inú ìwé tí a kọ lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ sí ni ibùdó rẹ̀ àkọ́kọ́, nígbà tí ti lítíréṣọ̀ alohùn jẹ́ ojú agbo ìṣeré; ìṣẹ̀dá kì í papọ̀ mọ́ ìṣere nínú

lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ, ṣùgbọ́n méjèèjì lè papọ̀ nínú lítíréṣọ̀ alohùn; a máa ń sábàá mọ olùṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ, ṣùgbọ́n a kì í sábàá mọ ti alohùn; ètò pàtó àti ìṣupọ̀ máa ń wà nínú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ, ó lè má sí ní ti alohùn, àyàbá ni ó máa ń wọ́ pọ̀ níbẹ̀; àwítúnwí kì í wọ́pọ̀ nínú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ, ó máa ń wọ́pọ̀ nínú ti alohùn;ọ̀gangan ipò lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ kò wọnú lítíréṣọ̀ nàà típẹ̀típẹ́ níi ti lítíréṣọ̀ alohùn; kò sí ètò ìkọ́ṣẹ́ lábẹ́ ọ̀gá nínú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ, ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà ni ó pọndandan ṣùgbọ́n ètò ìkọ́ṣẹ́ lábẹ́ ọ̀gá wà nínú púpọ̀ àwọn lítíréṣọ̀ alohùn.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ṣàlàyé ní ṣókí lórí àwọn ìtumọ̀ méjì tí lítíréṣọ̀ ní lóde òní.
2. Dá orúkọ méjì míràn tí àwọn onímọ̀ tún ń pe lítíréṣọ̀ alohùn, kí o sì ṣe àlàyé ìtumọ̀ wọn.
3. Sọ ìjọra méjì àti ìyàtọ̀ mẹ́rin láàrin lítíréṣọ̀ alohùn àti titàpilẹ̀kọ.
4. Kín ni èrò rẹ lórí àbá wí pé lítíréṣọ̀ alohùn jẹ́ lítíréṣọ̀ àbáláyé tí ó wà fúngbogbogbòò láwùjọ?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Àtàndá,J. A. *A Comprehensive History of the Yorùbá People Up to 1800*, G. O.Oguntómisìn (Olóòtú) John archers (Publishers) Ltd., Ibadan

Etymology of Literature, www.scribd.com

Finnegan, R. 1970,*Oral Literature in African*. Clarendon Press.Nairobi

Finnegan, R. 1992, *Oral Traditions and the Verbal Arts: A Guide to Research Practices*, Routledge, London.

Ilesanmi, T. M. 2004, *Yorùbá Orature and Literature: A cultural analysis*, Ọbáfẹ́mi Awolọ́wọ̀ University Press Ltd.,Ilé Ifẹ̀

Kennth Rexroth, Literature, nínú Brittanica Online Encylopedia, www.britannica.com

Ong, W. J. 1989,*Orality and Literacy: The Technologizing of the World*, Routledge, London.

Sartre, J. 1950, *What is Literature*, (Trasnlated from French by Benard Fretchman),Methuen & Co Ltd. 1983 reprint. London.

# ÌPÍN 2 ÌPÈNÍJÀINÚ Ẹ̀KỌ́ LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN I: OKO ÌWÁDÌÍ LÍLỌ

## ÀKÓÓNÚ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbààti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánlẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ṣaájú Lílọ sí Oko Ìwádìí
  4.1.1 Ìpalẹ̀mọ́ fún Oko Ìwádìí Lílọ
  4.1.2 Ní Oko Ìwádìí
  4.1.3 Ní Gbàrà tí A bá ti Oko Ìwádìí dé
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú ìpín kejì yí àti èyí tí ó tẹ̀lé e ni a óò ti jíròrò lórí àwọn ìpèníjà ìpìlẹ̀, tí kíkọ́ ẹ̀kọ́ lítíréṣọ̀ alohùn ní. Ohun tí ó fa sábàbí ìpèníjà yí ni pé àṣà ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà ni ìkẹ́kọ̀ọ́ ní ilé ẹ̀kọ́ òde òní dúró lé. Àṣà yí sì ṣàjèjì sí àṣà ìlohùn tàbí tàtẹnudẹ́nu tí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá dúró lé láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀.  Kí a wá tó lè kẹ́kọ̀ọ́ nípa lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá náà ní àwọn ilé ẹ̀kọ́ ìgbàlódé ní àkọ́yege, a gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ sọ lítíréṣọ̀ náà di kíkọ sílẹ̀ sínú ìwé. Ṣíṣe àkójọ àwọn lítíréṣọ̀ alohùn wọ̀nyí ṣe pàtàkì láti kojú ìpèníjà yìí. Lílọ sí oko ìwádí pọn dandan bí a bá fẹ́ ṣe àṣeyọrí. Oko ìwádìí lílọ máa ń fún olùwádìí ní àǹfàní láti ní ẹ̀kún rẹ́rẹ́ òye nípa irú ọnà ẹnu tí ó fẹ́ ṣeṣẹ́ lé gẹ́gẹ́ bí akópa (olùwòran). Lóòtọ́ ni ó ṣe é ṣe kí olùwádìí rán àwọn olùrànlọ́wọ́ iṣẹ́ ìwádìí lọ sí oko ìwádìí láti gba ohùn sílẹ̀, kí wọn sì wá jíṣẹ́ fún un nílé, ṣùgbọ́n èyí kò ní í fún olùwádìí náà ní àǹfàní láti ní òye kíkún gẹ́gẹ́ bí akópa. Nígbà tí iṣẹ́ ìwádìí bá fẹjú tí àkókò kò sì sí ni irú ètò yí wúlò fún.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI AFOJÚSÙN

Ní opin ìdánilẹ́kọ̀ọ́inú ìpín yìí, o ó ti lè sọ bí o ó ṣe palẹ̀mọ́ fún lílọ sí oko ìwádìí; bí o ó ṣe dé ọ̀dọ̀ àwọn abẹ́nà ìmọ̀ rẹ, irú àwọn ohun èlò tí ó nílò, gbogbo àwọn ìgbésẹ̀ tí ó yẹ kí o gbé ṣaájú lílọ sí oko ìwádií àti ni oko ìwádìí, àwọn irú ìjákulẹ̀ tí ó lè bá pàdé àti ohun tí o niláti ṣe kí irú rẹ̀ má wáyé, bí ó bá sì wáyé, ìgbésẹ̀ tí o óò gbé láti yanjú rẹ̀. Lọ́rọ̀ kan, óyẹ kí o ní ìgboyà láti lọ oko ìwádìí lẹ́yìn tí o bá ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán.

## 3.0 ÌBÉÉRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ní ṣókí kín ni ìpèníjà tí ìkẹ́kọ̀ọ́ lítíréṣọ̀ alohùun ní?
2. Kín ni ìdí tí oko ìwádìí lílọ fi ṣe pàtàkì nínú ìkẹ́kọ̀ọ́ lítíréṣọ̀ alohùn?
3. Dárúkọ àwọn ohun èlò mẹ́rin tí olùwádìí níláti mú lọ sí oko ìwádìí.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

**4.1** Ṣaájú Lílọ sí Oko Ìwádìí Yíyan lítíréṣọ alohun tí akẹ́kọ̀ọ́/olùwádìí yóò ṣiṣẹ́ lé lórí ni ohun akọ́kọ́. Tí kì í bá ṣe pé a yan ìkan fúnni, ó di dandan kí èèyàn ṣe ìwádìí ní yàrá ìkówèé-pamọ́-sí láti mọ ibi tí wọn kò ì tí ì ṣiṣẹ́ dé. Nítorí púpọ̀ àwọn ọnà ẹnu Yorùbá ni kò tí ì di kíkọ sílẹ̀, ó máa ń dára wí pé kí á ṣiṣẹ́ lórí lítíréṣọ̀ alohùn tí kò tí ì ní àkọsílẹ̀ tẹ́lẹ̀. Yálà a yan lítíréṣọ̀ alohùn tí a ó ṣiṣẹ́ lé lórí fúnni tàbí a yàn fúnra ẹni, lílọ kàwé ní láíbìrì pọn dandan láti mọ irú iṣẹ́ tí ó wà nílẹ̀ àti ibi tí iṣẹ́ kù sí, àti láti ní òye nípa àdúgbò oko ìwádìí àti àyíka rẹ̀. Àkókò yí ni olùwádí yóò ti bẹ̀rẹ̀ sí ṣe àkójọ àwọn àtòjọ ìbéèrè tí yóò béèrè lọ́wọ́ àwọn abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀. Irú lítíréṣọ̀ alohùn bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ ohùn pípè, orin, orò ilé tàbí tìlú, ọdún ìbílẹ̀, àlọ́ onítàn, abbl. Ohun tí ó kàn ni bí olùwádìí yóò ṣe dé ọ̀dọ̀ àwọn abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀; ìyẹn àwọn onílítíréṣọ̀ alohùn tí ó fẹ́ ṣiṣẹ́ lé lórí. Ó máa ń dára kí olùwádìí ní alárinà, ìyẹn ẹni tí yóò dúro bíí alagàta láàrin òun àti àwọn abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀ náà. Alárinà yí gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí àwọn olùwádìí àti abẹ́nà ìmọ̀ náà mọ̀ dáradára tí wọ́n sì fọkàn tán. Èyí yóò ṣe ìrànwọ́ ńlá fún àjọṣe tí ó dán mọ́rán láàrin ikọ̀ méjèèjì. Lẹ́yìn tí alárinà bá ti mú olùwádìí dọ́dọ̀ àwọn abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀ tán, tí wọn sì ti jẹ́ kí abẹ́nà ìmọ̀ mọ̀ pé òún fẹ ṣe àgbàsílẹ̀ lítíréṣọ̀ alóhùn wọn fún ìkẹ́kọ̀ọ́ àti pàápàá kí àkọsílẹ̀ nípa rẹ̀ lè wà fún ìran tí ń bọ̀, tí abẹ́nà ìmọ̀ sì ti gbà láti bá olùwádìí fọwọ́sowọ́pọ̀, ohun tí ó kàn ni àdéhùn ṣíṣe nípa àkókò ìgbohùn sílẹ̀ àti ohun tí àwọn abẹ́nà ìmọ̀ náà yóò bá gbà lọ́wọ́ olùwádìí gẹ́gẹ́ bí owó ọ̀yà. Ó máa ń dára kí alárinà jẹ́ ẹlẹ́rìí sí àdéhùn yìí torí kí ọ̀rọ̀ naà má baà di àríyànjiyàn lẹ́yìn-ò-rẹyìn. Ṣùgbọ́n ó gbọ́dọ̀ yé olùwádìí pé wọ̀fún ni gbogbo àdéhùn yìí.

Ọmọlúwàbí ni a fi ń ṣe púpọ̀ nínú rẹ̀, kì í ṣe ọ̀rọ̀ òfin. Nítorí náà sùúrù àti ìwà pẹ̀lẹ́ ni o lè fi yanjú èdè àìyedè nígbàkúgbà tí ó bá wáyé, pàápàá jùlọ nígbà tí àdéhùn bá yẹ̀. Nígbà míràn, ó ṣe é ṣe kí alárinà bá olùwádí ṣe gbogbo ètò ìṣaájú wọ̀nyí, ṣùgbọ́n àǹfààní wà nínú kí olùwádí ti fojúrinjú fún ìgbà àkọ́kọ́ pẹ̀lú abẹ́nà ìmọ̀ ní àkókò ìfẹnukò náà ṣaájú àkókò gbígba ohùn sílẹ̀. Yàtọ̀ sí àwọn ohun tí olùwádìí ti lè kà nípa agbègbè oko ìwádìí tí ó ń lọ nínú ìwé àti àwọn ohun yòówù tí ì báà ti gbọ́ nípa àdúgbò náà, tí olùwádìí kò bá tí ì dé àdùgbò náà rí, àkókò ìfojúrinjú pẹ̀lú abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀ ni yóò kọ́kọ́ ní ìrírí ara rẹ̀ gan-an, tí yóò túbọ̀ ràn án lọ́wọ́ nínú ìpalẹ̀mọ́ rẹ̀.

### 4.1.1 Ìpalẹ̀mọ̀ fún Oko Ìwádìí Lílọ

Lẹ́yìn ìfẹnukò fún gbígba ohùn sílẹ̀, ohun tí ó kù ni mímúrasílẹ̀ fún lílọ sí oko ìwádìí náà, ní ibi tí ìgbohùn sílẹ̀ yóò ti wáyé. Yàtọ̀ sí àtojọ ìbéèrè, àwọn ohun èlò ìgbohùn sílẹ̀ àti èròjà wọn bíi rìkọ́dà, téèpù, kámẹ́rà tí ó lè ya fọ́tò àti fídíò pẹ̀lú gbogbo fọ́n-ọ́n-rán tàbí téèpù wọn àti bátìrì tí ìkọ̀ọ̀kan nílò pọn dandan. Rìkọ́dà ọlọ́bọrọgidi (tí kì í lo téèpù) àti kámẹ̀rà onídíjítáàlì, (ti kì í lo fíìmù) ti wà lóde òní, kódà ènìyàn lè lo fóònù rẹ̀ láti ká ohùn àti fídíò sílẹ̀ èèyàn si lè fi ya fótò àti fídíò pàápàá.

Ṣùgbọ́n ẹni tí yóò bá lo fóònù rẹ̀ fún irú iṣẹ́ yìí gbọ́dọ̀ rí i pé èyí tí ó gbéwọ̀n dáadáa ni òún lò. Àbá tí ó dára ni pé kí olùwádìí má ṣe lo ẹrọ fóònù gẹ́gẹ́ bí ojúlówó ohun èlò ìgbohùnsílẹ̀. Ó lè lò ó bí amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ṣá. Gẹ́gẹ́ bí Ògúnjìnmí àti Na’Allah (2000)náà ti dábàá, olùwádìí gbọ́dọ̀ ní ẹ̀kún rẹ́rẹ́ ìmọ̀ nípa ìṣiṣẹ́ àti àmúlò àwọn ẹ̀rọ àti ohun èlò ìgbohùnsílẹ̀ tí ó ń kó lọ sí oko ìwádìí. Ìyẹn ni pé ó gbọ́dọ̀ lè ṣe ìmúlò gbogbo rẹ̀ fúnra rẹ̀ dáradára. Lọ́pọ̀ ìgbà, olùwádìí máa ń nílò olùrànlọ́wọ́ tí yóò bá a gbá àwón ẹ̀rọ ìgbohùn sílẹ̀ àti tìyàwòrán mú, pàápàá tí iṣẹ́ rẹ̀ bá fẹjú tí ó sì ju ọjọ́ kan ṣoṣo lọ.

Olùwádìí gbọ́dọ̀ wá olùrànlọwọ́ tí ó ṣe é gbẹ́kẹ̀ lé. Ohun kan tí olùwádìí kò gbọdọ̀ gbàgbé ni dídán gbógbó àwọn ohun èlò tí ó ń kó lọ sí oko ìwádìí wò, kí ó sì rí i pé gbogbo wọn ń ṣiṣẹ́ dáradára. Àìṣe èyí lè já sí àbámọ̀ nígbẹ̀yìn, pàápàá tí ó bá dé oko ìwádìí tán, tí ó wa ṣẹ̀ṣẹ̀ rí i pé ìkan tàbí méjìi kò ṣiṣẹ́ dáadáa. Èyí lè ṣe àkóbá ńlá fún iṣẹ́ ìwádìí náà láti ìbẹ̀rẹ̀. Gbogbo àwọn ohun èlò pátápátá, pàápàá bátìrì àti téèpù, ni olùwádìí gbọ́dọ̀ rí i pé ó tó, kí ó sì tún ṣẹ́kù torí a kì í ba à á mọ̀.

Yàtọ̀ sí àwọn ohun èlò ìgbohùnsílẹ̀ àti èròjà wọn, gbogbo ohun tí óbá máa mú iṣẹ́ náà rọrùn ni ó yẹ kí olùwádìí mú dáni. Àwọn òògùn kékèèké bí èyí tí ó wà fún ẹ̀fọ́ríàti ibà, ìpara tí ó lè lé ẹ̀fọn àti àwọn kòkòrò sẹ́yìn, pẹ̀lú àwọn òògun tí èèyàn lè bù sójú ọgbẹ́ tuntun tí ẹ̀jẹ̀ yóò fi dá nítorí ìfarapa.

Ó máa ń dára láti gba àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára tí ó bá nílò. Olùwádìí sì ti gbọ́dọ̀ lo òògùn àjẹsára ibà màlẹ́ríà. Ìdí tí èyí fi pọn dandan ni pé olùwadìí kò gbọdọ̀ ṣàìsàn nígbà tí ó wà ní oko ìwádìí, tí èyí bá wáyé yóò pa iṣẹ́ ìwádìí ní oko ìwádìí náà lára. Ó máa ń dára láti mú àwọn nǹkan ìpanu dáni tí olùwádìí àti àwọn olùrànlọ́wọ́ rẹ̀ lè jẹ. Irú àwọn ohun ìpanu náà sì tún lè wúlò fún àwọn ọmọdé ní àwùjọ oko ìwádìí. Olùwádìí gbọ́dọ̀ fa ojú àwọn ènìyàn àwùjọ tí ó ti ń lọ ṣèwádìí mọ́ra dáadáa kí wọ́n baà túraká sí i kí ó sì lè rí ohun tí ó fẹ́ gbà lọ́wọ́ wọn gbà. Lára ọ̀nà láti ṣe èyí ni ọwọ́ lílà sí wọn. Ó dára kí olùwádìí mú ẹ̀bùn dáni fún àwọn ìyàwó tàbí ọkọ àti ọmọ abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀. Kí olùwádìí tó kúrò ní ilé lọ sóko ìwádìí, ó gbọ́dọ̀ ṣètò owónàà àti gbogbo ohun tí yóò bá fi fẹ̀mí ìmoore

hàn sí àwọn abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀ àti ìdílé wọn. Pàtàkì sì ni ọ̀rọ̀ owó ọ̀yà tí òun àti àwọn abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀ fẹnukò sí tẹ́lẹ̀.

## 4.2 Ní Oko Ìwádìí

Ó máa ń dára kí ó jẹ́ pé ọ̀gangan ipò lítíréṣọ̀ alohùn tí a fẹ́ ṣíṣẹ́ lé gan-an ni a ti lọ gbà á sílẹ̀; ní ibi ìṣeré tàbí ojú agbo eré tí àwọn òṣèré àti òǹwòran yóò ti fi ojú ko ojú. Ìwà ọmọlúwàbí híhù bíi ìkíni, ọ̀yàyà, àti pàápàá ìrẹ̀lẹ̀ pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ sùúrù ni olùwádìí tún nílò gidigidi láti ṣe àṣeyọrí ní oko ìwádìí. Bí àpẹẹrẹ, tí àwọn abẹ́nà ìmọ̀ kò bá tétè dá olùwádìí lóhùn tàbí tí àdéhùn bá yẹ̀, olùwádìí kò gbọdọ̀ fi ṣe ìbínú. Ìmúra olùwádìí tún gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí yóò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà sí àwọn tí ó fẹ́ gba ohùn wọn sílẹ̀. Kò gbọdọ̀ múra bí alákọ̀wé tàbí ẹni tí kò bìkítà. Ó sì gbọdọ̀ ṣe tán láti dara pọ̀ mọ́ wọn ninú ohun gbogbo tí wọ́n bá ń ṣe. Gbogbo èyí ni yóò jẹ́ kí wọ́n lè fọkàn tán an láìbẹ̀rù, kí wọ́ sì dá a lóhùn dáradára.

Gbígba ohùn sílẹ̀ ní oko ìwádìí pín sí ọ̀nà méjì. Àkọ́kọ́ ni ti gbígba lítíréṣọ̀ alohùn tí a fẹ́ ṣíṣẹ́ lé lórí gan-an. Èkejì sì ni ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò nípa ọnà ẹnu náà. Lẹ́yìn tí a bá ṣe tàkọ́kọ́ tán ni a óò tó ó ṣe tìkejì. Ó lè jẹ́ ní ọjọ́ kan náà; bí a ti ń ṣe ti àkọ́kọ́ tán, ó sì lè jẹ́ pé a óò tún fi àkókò sí i. Nínú ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò yí ni olùwádìí yóò ti béèrè gbogbo àwọn ìbéèrè nípa ìtàn orírún àti nípa ìmúlò àti ọ̀rọ̀ ajẹmáwùjọ ọnà ohùn tí ó gbà sílẹ̀. Àwọn ìbéèrè tí ó ti kọ wá láti ilé àti àwọn tuntun tí ó ṣuyọ ní àkókò ìṣeré, tí ìgbohùn sílẹ̀ ń lọ lọ́wọ́ lójú agbo eré ni yóò jẹ́ bíbèèrè. Kì í ṣe wí pé ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò kò lè wáyé ṣaájú gbígba lítíréṣọ̀ alohùn sílẹ̀; kí àǹfàní baà wà láti béèrè ìbéèrè nípa ìṣeré papọ̀ mọ́ tàwọn ti olùwádìí ti kọ wá látilé, kí ó sì má baà di iṣẹ́ ẹ̀ẹ̀mejì, ni àbá wí pé lẹ́yìn gbígba lítíréṣọ̀-alohùn-sílẹ̀ ni ìfọ̀rọ-wáni-lẹ́nu-wò tó yẹ kó wáyé gùn lé. Tí olùwádìí bá lo olùrànlọ́wọ́ ní akòkò ìgbóhùnsílẹ̀ méjèèjì yìí, ojúṣe olùwádìí ni títọ́ olùràlọ́wọ́ rẹ̀ sọ́nà níbàámu pẹ̀lú àfojúsùn iṣẹ́ ìwádìí rẹ̀. Àǹfàní tí ó wà nínú lílo olùrànlọ́wọ́ láti bá olùwádìí gbá àwọn ẹ̀rọ ìgbohùnsílẹ̀ àti tàwòrán yíyà mú ni pé olùwádìí yóò lè fọkàn sí ojúṣe rẹ̀ bí akópa nínú àgbékálẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn náà àti ṣíṣàkójọ ìbéèrè fún ìfọ̀rọ̀wá-ni-lẹ́nu-wò lẹ́yìn gbígba lítíréṣọ̀ alohùn síllẹ̀. Ohun tí èyí tọ́ka sí ni pé púpọ̀ nínú ìdarí àti ìtọ́sọ́nà tí olùwádìí fẹ́ ẹ́ fún olùrànlọ́wọ́ iṣẹ́ ìwádìí rẹ̀ ti gbọ́dọ̀ wáyé ṣaájú ìgbohùn sílẹ̀.

Gbogbo àwọn fọ́n-ọ́n-rán tí olùwádìí gbohùn sí pátápátá ni ó gbọ́dọ̀ kọ àkọlé sí láti sàmì sí lọ́kọ̀ọ̀kan kí wọn baà ṣeé dá mọ̀ ní kíákíá tí ó bá délé. Lára àwọn ohun tí kò gbọdọ̀ má sí ní inú àwọn àkọlé náà ni ọjọ́ tí a ṣe ìgbohùnsílẹ̀, àkókò àti ibi tí a ti ṣe é, orúkọ ọnà ohùn tí a gbà sílẹ̀ àti ti àwọn òṣèré àti abẹ́nà ìmọ̀ náà. Pátàkì si ni sísàmì sí téèpù tí a gbohùn sí gẹ́gẹ́ bí ojúlówó téèpù tí kò fi ní í dàpọ̀ mọ́ àwọn ẹ̀dà rẹ̀ tí a bá ṣe lẹ́yìn-ọ̀rẹyìn. Ó yè kí n tẹnu mọ́ ọn fún ọ pé yíya àwòrán onífọ́tò àti onífídíò ní àkókò ìgbohùnsílẹ̀ méjèèjì tí a ti sọ̀rọ̀ bá ṣe pàtàkì púpọ̀.

## 4.3 Ní Gbàrà tí A báti Oko Ìwádìí dé

Ohun tí ó yẹ kí á kọ́kọ́ ṣe bí a ti ń ti oko ìwádìí dé ni ṣíṣẹ̀dà àwọn ojúlówó téèpù tí a gba lítíréṣọ̀ alohùn sí, èyí tí a mú dé láti oko ìwádìí. Àwọn ẹ̀dà tí a ṣe wọ̀nyí ni a ó máa lò láti fi ṣe iṣẹ́ ní ilé. Nítorí náà ó yẹ kí á ya àwọn ẹ̀dà náà sọ́tọ̀ nípa kíkọ àkọlé, 'Ẹ̀dà Àmúṣiṣẹ́' sí wọn lára. Ojúlówó téèpù, tí a mú bọ̀ láti oko ìwádìí ni a gbọ́dọ̀ ṣe lọ́jọ̀ sí ibi tí kò tí ní í bàjẹ́. Bí fọ́n-ọ́n-rán ẹ̀dà àmúṣiṣẹ́ bá bàjẹ́, a óò ní àǹfàní láti ṣe ẹ̀dà míràn láti inú ojúlówó fọ́n-ọ́n-rán tí a ṣe lọ́jọ̀. Ṣùgbọ́n tí ó bá jẹ́ àwọn ohun èlò ọlọ́bọrọgidi, onídíjitáàlì ni olùwádìí fi gba ohùn sílẹ̀ lóko ìwádìí, yóò kọ́kọ́ gbé e sí orí kọ̀ńpútà, kí ó tó wa ṣe ẹ̀dà rẹ̀ sórí dísíìkì. Ó dárá láti ṣe ẹ̀dà méjì sórí dísíìkì. Kí ọ̀kan wà nípamọ torí a kò mọ̀ ohun tí ó le ṣẹlẹ̀ láìròtẹ́lẹ̀ sí dísíìkì náà (tàbí èyí tí ó tilẹ̀ wà lórí ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà), kí ìkejì sì jẹ́ èyí tí a óò máa múlò fún iṣẹ́ ṣíṣe. A gbọ́dọ̀ sàmì ìpàálà sáàrin oríṣìídísíìkì méjèèjì kí wọ́n má baà dàpọ̀. A tún lè fi ẹ̀dà orí kọ̀ǹpútà pamọ́ síbẹ̀ náà. Gbogbo ẹ̀rọ alòlẹ́ńtíríìkì àti èròjà wọn bíi dísíìkì yẹn ni ó lè sọṣẹ́ sílẹ̀ nígbàkígbà. Bí ìkan bá bàjẹ́, a óò rí òmíràn lò.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú, níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́pé sísọ lẹ́nu ni gbòǹgbò tí ó gbé lítíréṣọ̀ alohùn dúró, a gbọ́dọ̀ kọ ọ́ sílẹ̀ sínú ìwé, tí a óò bá kẹ́kọ̀ọ́ nípa rẹ̀ ní àkọ́yanjú. Ìdí ni pé kíkọ sílẹ̀ sínú ìwé ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ ètò ìkẹ́kọ̀ọ́ lóde òní. Ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ nínú akitiyan láti dojúkọ ìpènijà àtisọ lítíréṣọ̀ alohùn di kíkọ sínú ìwé, lati mú ìkẹ́kọ̀ọ́ nípa rẹ̀ rọrùn, ni a gbé yẹ̀wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Apá mẹ́rin ni a pín ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín náà sí.

- Ní apá kìn-ín-ní ni a ti ṣàlàyé ohun tí olùwádìí yóò ṣe ṣaájú dídábàá lílọ sí oko ìwádìí. A ní ó gbọ́dọ̀ yan ọnà ohùn tí yóò ṣiṣẹ́ lé lórí, ó sì gbọdọ̀ wá alárinà tí yóò mú un dé ọ̀dọ̀ àwọn abẹ́nà ìmọ̀ tí yóò gba ọna ohùn náà lẹ́nu wọn. Alárinà yìí ni yóò fi olùwádìí mọ àwọn abẹ́nà ìmọ̀ tí wọn ó fi fẹnukò nípa ọjọ́ tí wọn óò gba ohùn sílẹ̀.
- Ní apá kejì ni a ti sọ pé ohun tí ó kàn lẹ́yìn ìfẹnukò yìí ni pípalẹ̀mọ́ ní pẹ́rẹwu fún lílọ sóko ìwádìí. A ní olùwádìí gbọ́dọ̀ lọ kàwé ní láíbìrì kí ó sì ní àtòjọ ìbéèrè nípa ọnà ohùn tí ó fẹ lọ oko ìwádìí lé lórí. Ó tún gbọ́dọ̀ ṣètò ohun èlò ìgbohùnsílẹ̀ àti àwọn èròjà wọn kí ó sì rí i pé wọ́n ń ṣiṣẹ́ dárádára. A sì sọ pé ó gbọ́dọ̀ ṣètò fún ìlera ara rẹ̀ àti ohun tí yóò fí fi ìmoore hàn, yàtọ̀ sí owó ọ̀yà tí wọ́n ti jọ fẹnu kò lé lórí.
- Apá kẹta ni a ti sọ̀rọ̀ oko ìwádìí gan-an. A sọ pé ní ojú agbo eré níbi ọ̀gangan ipò ọnà ohùn tí a fẹ́ gbà sílẹ̀ ni ó dára jùlọ láti ṣe ìgbàsílẹ̀ lítiréṣọ̀ alohùn. A tọ́ka sí i pé kí olùwádìí baà bá ojúrere àwọn onílítíreṣọ̀ alohùn náà pàdé, kí wọ́n sì dá a lóhùn dáadáa, ó gbọ́dọ̀ fi ìwà ọmọlúwàbí bá wọn lò pọ̀. Ìmúra rẹ̀ gbọ́dọ̀ bá ti àwọn ènìyàn tí ó ńlọ gba ohùn lẹ́nu wọn mu, kí wọn baà rí i bí ìkan lara

wọn dípò àjèjì. Á sọ pé ó gbọ̀dọ̀ lawọ̀ sí wọn, kí ó ní ọ̀yàyà, kí ó sì fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ sùúrù àti ìrẹ̀lẹ̀ bá wọn lò. Ọ̀nà méjì tí a ní ìgbohùnsílẹ̀ pín sí ni ti gbígba lítíréṣọ̀ alohùn náà gan-an sílẹ̀ àti ti ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò. Àsọyé àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ tí ó ga ni a tọ́ka sí pé ó gbọ́dọ̀ wà láàrin olùwádìí àti olùrànlọ́wọ́ rẹ̀. A ṣàlàyé pé olùwádìí gbọ́dọ̀ sàmì sí àwọn ojúlówó fọ́n-ọ́n-rán tí ó fi gbohùn sílẹ̀ ní oko ìwádìí fún ìdámọ̀ tí ó péye kí ó tó kúrò ní oko ìwádìí.

- Ìgbésẹ̀ àkọ́gbé lẹ́yìn àbọ̀dé oko ìwádìí ni a ṣe àlàyé lé lórí ní apa kẹrin. A ní olùwádìí gbọ́dọ̀ ṣe ẹ̀dà àwọn ojúlówó fọ́n-ọ́n-ran tí ó gba ohùn sí ní oko ìwádìí, kí ó tó ṣe wọn lọ́jọ̀ síbi tí wọn kò ti lè bàjẹ́, bí ó bá sì jẹ́ ẹ̀rọ àgbóhùnsílẹ̀ onídíjítáàlì tí kì í lo téèpu ni olùwádìí lò ní oko ìwádìí, ó pọ́n dandán kí ó gba ohùn orí rẹ̀ sílẹ̀ sórí ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà kí ó tó ṣe ẹ̀dà rẹ̀ sórí dísíìkì. A ní ó gbọ́dọ̀ṣe ẹ̀dà méjì, ó kéré tán, ìkan yóò jẹ́ ṣiṣe lọ́jọ̀, ìkejì ni àmúṣiṣẹ́.

Ohun kan tí akò gbọdọ́ ṣàìsọ ni pé àwọn ìlànà tí a gbé kalẹ̀ wọ̀nyí kì í ṣe òfin rigidi. Olùwádìí níláti máa ṣàmúlò wọn ni ìbámu pẹ̀lú àmójúsùn iṣẹ́ rẹ̀ ni. Lára àwọn ohun tí ó ṣe é ṣe kí ó ní ipa lórí àmúlò àwọn ìlànà náà ni irú ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn tí à ń ṣiṣẹ́ lé lórí, àṣà àti ìlànà tí ó rọ̀ mọ́ lítíréṣọ̀ alohùn náà, ojú àmúwayé , èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn onílítíréṣọ̀ alohùn náà ati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ṣe àlàyé ṣókí lórí ìpalẹ̀mọ́ olùwádìí láti lọ sí oko ìwádìí.
2. Ṣe ẹ̀kún rẹ́rẹ́ àlàyé lórí ojúṣe alárenà nípa ìwádìí ọnà ohùn Yorùbá.
3. Dárúkọ àwọn ọ̀nà méjì pàtàkì tí ìgbohùnsílẹ̀ lórí ọnà ohùn pín sí, kí o sì ṣe àlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.
4. Ṣàlàyé àwọn ọgbọ́n tí olùwádìí le dá láti tọ́jú àwọn ohùn tí ó gbà ti oko ìwádìí bọ̀ ní ìgbà tí ó bá darí délé.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Abímbọla, Wándé. 1982. Notes on the Collection, Transcription, Translation and analysis of Yorùbá Oral Literature, ninú Afọlayan, A. Yorùbá Language and Literature.

Adékọlá, O. O. Anthropological field Method: A Researcher's Approach, nínú Délé Láyíwọlá (Olóòtú),*A Handbook of Methodologies in African Studies*, John Archers (Publishers Ltd.) Ìbàdàn, fún Institute of African Studies, Yunifásítì ti Ìbàdàn, Ìbàdàn

Finnegan, R. 1992, *Oral Traditions and the Verbal Arts: A Guide to Research Practices,* Routledge, London.

Ògúndèjì, P.A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. Ìbàdàn: Centre for External Studies,University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Ògúnjìmí, B. àti Na'Allah A. 1991*Introduction to African Oral Literature: Vol I- Prose*. Unilọrin Press, Ìlọrin.
_______________________1994*Introduction to African Oral Literature: Vol II- Poetry*. Unilọrin Press, Ìlọrin.

# ÌPÍN 3 ÌPÈNÍJÀ INÚẸ̀KỌ́ LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN II:ÀBỌ̀ OKO ÌWÁDÌÍ

## AKÓÓNÚ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Ṣíṣe Ìdàkọ
 4.2 Ṣíṣe Iṣẹ́ Ògbifọ̀
 4.3 Ṣíṣe Ìtúpalẹ̀
  4.3.1 Àmúlò Tíọ̀rì
 4.4 Ọ̀rọ̀ Ìṣẹ̀tọ́
 4.5 Pípadà lọ sí Oko Ìwádìí
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

**1.0** Ìfáárà Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ kà tán, a ti jíròrò lórí akitiyan tí a nílò láti ṣe kí á lè kojú apá kan lára ìpèníjà tí ń bẹ nínú kíkọ́ ẹ̀kọ́ lítíréṣọ̀ alohùn. Ìpeníjà tí a jíròrò lé lórí náà ni ti bí a óò ṣe lọ sí oko ìwádìí láti gba ohùn ìṣeré lítíréṣọ̀ alohùn àti àwọn àlàyé tí ó wúlò nípa wọn sílẹ̀. A jíròrò lórí àwọn ìgbésẹ̀ tí óyẹ kí olùwádìí gbé ṣaájú lílọ sí oko ìwádìí (pàápàá láti palẹ̀mọ́ dáradára), ní oko ìwádìí àti ní gbàrà tí ó bá ti oko ìwádìí dé. Ní ìhín ni a óò ti jíròrò lórí àwọn akitiyan jíjábọ̀ iṣẹ́ oko ìwádìí. Lẹ́yìn tí olùwádìí bá sì ti oko ìwádìí dé ni iṣẹ́ èyí máa ń bẹ̀rẹ̀ ní pẹ́rẹu. Ìyẹn ni pé fifi ìpìlẹ̀ lélẹ̀ ni lílọ sí oko ìwádìí jẹ́ fún àwọn akitiyan jíjábọ̀ yìí. Nípasẹ̀ akitiyan jíjábọ̀ yìí ni olùwádìí yóò fi sọ lítíréṣọ̀ alohùn tí ó ti fi ẹ̀rọ ìgbohùn-sílẹ̀ ká sórí fọ́n-ọ́n-rán téèpù tàbí tí ó ti ṣe ẹ̀dà rẹ̀ sórí dísíìkì di kíkọ sílẹ̀ sínú ìwé.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Nígbà tí o bá ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán, o ó ti lè sọ nípa àwọn ìpèníjà tí olùwádìí yóò kojú nígbà tí ó bá ń ṣe ìdàkọ, ògbifọ̀ àti ìtúpalẹ̀ lámèétọ́ lítíréṣọ̀ alohùn, oó sì lè sọ ọ̀nà abáyọ sí àwọn ìpèníjà náà. O ó lè ṣe àlàyé nípa àwọn tíọ̀rì tí ó wúlò fún ṣíṣe ìtúpalẹ̀ pẹ̀lú, àti nípa ìṣẹ̀tọ́ nínú jíjábọ̀ iṣẹ́ ìwádìí lórí lítíréṣọ̀ alohùn.

## 3. 0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Kín ni ìdí tí olùwádìí kò fi gbọ́dọ̀ lo ojúlówó téèpù/dísíìkì tí ó ṣe lọ́jọ̀ láti ṣiṣẹ́ ìdakọ?
2. Kín ni àwọn ohun tí ó tún lè gbé olùwádìí padà lọ sí oko ìwádìí?

3. Ìlànà ṣíṣe ìdàkọ ewì wo ni ó dara jù? Kín ni ìdí tí ìlànà náà fi dára ju àwọn yòókù lọ?

# 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 Ṣíṣe Ìdàkọ

Ó pọn dandán láti rán wa létí ní ìhín wí pé ẹ̀dà téèpù/ dísíìkì àmúṣiṣẹ́ ni ólùwádìí yóò lò látiṣe ìdàkọ, kì í ṣe ojúlówó tàbí ẹ̀dà tí ó ṣe lọ́jọ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ tẹ́lẹ̀ ìdí ni wí pé tí èyí tí ó ń lò fi ṣiṣẹ́ bá bàjẹ́ yóò lè ṣe ẹ̀dà tuntun mìíràn látinu èyí tí ó fi pamọ.

Ohun àkọ́kọ́ tí a nílò láti pe àkíyèsí sí ni pé ṣiṣe ìdàkọ gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìfọkànsí àti sùúrù. Bí olùwádìí bá gbé iṣẹ́ ìdàkọ fún olùrànlọ́wọ́, ó gbọ́dọ̀ rí i pé òhun tí àwọn jọ fẹnukò lé lórí ni ó ṣe. Ìyẹn ni pé olùwádìí níláti ṣe àbójútó iṣẹ́ ìdakọnáà dáradára, kí ó rí i pé ọwọ́ aṣàdakọ tí ó ń ran òun lọ́wọ́ náà gún régé. Ǹí ọ̀pọ̀ ìgbà ni aṣàdàkọ yóò nílò láti tẹ́tí sílẹ̀ dáradára, kí ó sì tún àwọn ibi tí kò bá gbọ́ daradara gbọ́ léraléra. Gbogbo àwọn ibi tí kò bá wá gbọ́ dáradara lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ àgbọ́-tún-gbọ́-tún-gbọ́ ni yóò sàmì sí, tí yóò sì kó jọ ní ìrètí àtipadà lọ béèrè lọ́wọ́ àwọn tí ó gba ọnà ohùn náà lẹ́nu wọn ní oko ìwádìí.

Ohun kejì ni pé aṣàdàkọ gbọ́dọ̀ lo àkọtọ́ tí ó súnmọ́ bí a ṣe pe ọ̀rọ̀ lẹ́nu. Láti ran ẹnikẹ́ni tí yóò báka àkọsilẹ̀ náà lọ́jọ́ iwájú lọ́wọ́. Bí àpẹẹrẹ, gbogbo ibi tí a bá ti fa ohùn gùn, tí a ti gbọn ohùn tàbí tí a ti ránmú sọ̀rọ̀ ni ó yẹ kí aṣàdàkọ gbìyànjú láti tọ́ka sí nípa bí ó ṣe kọ wọ́n síl. Eléyìí yóò ran ẹni tí óbá ń kà á ní ọjọ́ iwájú lọ́wọ́ láti ní òye bí wọn ṣe pe ọ̀rọ̀ ní ojú agbo eré gan-an. Ìdí tí ó fi yẹ kí á pe àkíyèsí sí èyí dáadáa ni pé nínú àkọtọ́ èdè Yorùbá kò pọn dandan kí á ṣàfihàn àwọn wúnrẹ̀n aláìṣèyàtọ̀, tí kò ní ìtumọ̀ gírámà. Ṣùgbọ́n irú àwọn wúnrẹ̀n ohùn bẹ́ẹ̀ ṣe pàtàkì fún títọ́ka sí àgbékálẹ̀ ọ̀rọ̀, ìdí nìyí tí ó fi yẹ ní fífí hàn nínú àdàkọ lítíréṣọ̀ alohùn.

Ohun kẹta ninú ìpèníjà tí ó jẹ mọ́ dída ewì kọ ni bí a óò ṣe mọ òdiwọ̀n ìlà kọ̀ọ̀kan. Ìlànà onílàjilà ni a fi máa ń kọ ewì sílẹ̀. Báwo ni a óò ṣe mọ ibi tí ìlà kọ̀ọ̀kan dé nígbà tí a bá ńṣe ìdàkọ ewì alohùn?Èyí ni ìbéèrè tí akò lè ṣàìgbé yẹ̀wò. Gẹ́gẹ́ bí Ọlátúnjí (1984) ti fi yé wa, ìlànà mẹ́ta tí àwọn aṣaájú ti lò láti ṣòdiwọ̀n opin ìlà ewì ni

(i) ibi ìdánudúró díẹ̀,
(ii) ibi tí òye tàbí ìtumọ̀ kíkún wà pẹ̀lú
(iii) ibi àwítúnwí ìhun gbólóhùn, tàbí ká kúkú sọ pé ibi ìdọ́gba gbólóhùn. Bí lílo ibi ìdánudúró díẹ̀ tàbí ìséèmi ti wúlò tó náà ni ìṣoro rẹ̀ pọ̀. Ní àwọn ibi ìdánudúró díẹ̀ nígbà míràn, bí Ọlátúnjí (1984) ti sọ, ìtẹnu mọ́rọ̀ nípa lílo wúnrẹ̀n "o/oo/òò" tàbí fífa fáwẹ́lì

ìparí ọ̀rọ̀ gùn lè wáyé níbi ìparí ìlà. Èyí kì í ṣe gbogbo ìgbà, bí a ti tọ́ka sí i ṣaájú, ó sì wọ́pọ̀ nínú orin. Wo àpẹẹrẹ yìí:

Òru l'èèyàn-án bá wọn ná'jà ọlọ̀tẹ̀
Orí ni n ọ́ gbààààà
Nò gbowóóóó
Onídà ọmọ àrọ̀(Babalọlá, 2001: 226)

Ibi ìdánudúró díẹ̀, tí akéwì, tí ó ki oríkì ìran Ìlọ̀kọ́ yìí ti fa àwọn fáwẹ̀lì ìparí ọ̀rọ̀ gùn ni aṣàdakọ fi ṣe òpin àwọn ìlà ààrin méjèèjì yẹn.

Láti lo òdiwọ̀n ibi ìdánudúró díẹ̀ nìkan yóò mú ìṣoro dání nítorí akéwì alohùn kò ní ìlànà kan pató fún dídánudúró díẹ̀ tàbí sísé-èémí. Nígbà míràn ó lè máa yára kí ó rọ́ ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ pọ̀ tàbí kí ó máa danudúro ní ìdákúǹrekú-ìdákúǹrekú, bóya láti yọ àrà tàbí fún ìdí mìíràn. Ní irú àwọn ibi báwọ̀nyí, ṣíṣàmúlò ìlànà ìtumọ̀ kíkún àti ti ìdọ́gba gbólóhùn yóò wúlò púpọ̀. Bí àpẹẹrẹ tí akéwì kan bá rọ oríkì Ààrẹ Látòósà (ti ìlú Ìbàdàn láyé àtijọ́) papọ̀, tí kò dánu dúró títí ó fi dé orí "gegele," a lè kọ ọ́ báyìí:

"Pa sílé, pa sọjà, pa sídìí ọ̀gẹ̀dẹ̀, pa sídìí oroǹbó,
pa síkòtò, pa sí gegele"

Bí a bá wò ó dáradára, a óò rí i pé kò bóju mu láti fi gbogbo rẹ̀ ṣe ìlà ẹyọ kan ṣoṣo, bí aṣe gbìyànjú láti fi hàn yìí. Bí a bá ní kí á loìlànà ìbádọ́gba (ìhun) gbólóhùn nìkan ìlà mẹ́fà ni a óò fi gbogbo àrọ́pọ̀ náà ṣe, tí àpólà gbólóhùn kọ̀ọ̀kan yóò jẹ́ ìlà kọ̀ọ̀kan báyìí:

Pá sílé
Pa sọjà
Pa sídìí ọ̀gẹ̀dẹ̀
Pa sídìí oroǹbó
Pa síkòtò
Pa sí gegele

Ṣùgbọ́n bí a bá mú ìlànà ìtumọ̀ papọ̀ mọ́ ọn, ìlà mẹ́ta tí a óò fi ṣe nìyí:

Pá sílé, pa sọjà
Pa sídìí ọ̀gẹ̀dẹ̀, pa sídìí òroǹbó
Pa síkòtò, pa sí gegele

## 4.2 Ṣíṣe Iṣẹ́ Ògbifọ̀

Ìdí tí a fi nílò láti ṣe ògbifọ̀ lítíréṣọ̀ alohùn sí èdè mìíràn bí i Gẹ̀ẹ́sì, Faransé, Pàyán-àn, Potokí, tàbí èdè mìíràn ni láti jẹ́ kí àwọn lítíréṣọ̀ náà dé àrọ́wọ́tó àwọn elédè mìíràn káàkiri àgbáyé. Ó pọn dandan kí akẹ́kọ̀ọ́ tí ó jẹ́ olùwádìí, tí ó sì ń ṣe iṣẹ́ ìwádìí rẹ̀ ni ilé ẹ̀kọ́ gíga tí wọn kì í ti í lo èdè Yorùbá fún kíkọ irú iṣẹ́ ìwádìí bẹ́ẹ̀ ó ṣe ògbifọ̀ àwọn ohùn tí ó ti gbà sílẹ̀ sí èdè tí wọn bá ń fi ń jábọ̀ iṣẹ́ ìwadìí. Láti ṣeṣẹ́ ògbifọ̀ láti èdè kan sí

òmíràn kì í rọrùn nítorí àṣà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni àwọn èdè méjèèjì ti jẹyọ. Àwọn èrò àti irúfẹ́ ọnà èdè tí ó wà nínú èdè Yorùbá lè má sí nínú àwọn èdè òkè òkun tí a fẹ́ ṣògbifọ̀ sí. Ìdí nìyí tí olùwádìí ti ó ń ṣe ògbifọ̀ náà gbọ́dọ̀ fi máa ṣe àmúlò àlàyé kíkún nínú ìtọsẹ̀ ọ̀rọ̀. Gẹ́gẹ́ bí àbá àwọn onímọ̀ ìṣaájú ìtumọ̀ sí èdè míràn "...gbọ́dọ̀ lọ tààrà, ó sì gbọdọ̀ gbé òye yọ ní kíkún" (Abímbọla, 1982; Ògúndèjì, 1991:14). Yàtọ̀ sí ṣíṣe ògbifọ̀ sí àwọn èdè ilẹ̀ Yúróòpù, Àríwá àti Gúsù Amẹ́ríkà, tí a ti mẹ́nu bà, ṣíṣe ògbifọ̀ sí àwọn èdè ilẹ̀ Éṣíà náà tún wúlò ní àkókò bágbàmu yìí, tí ó jẹ́ pé àwón orílẹ̀ èdè bíi Ṣáínà àti Jèpáànì ni wọ́n ti ń fẹ ìbániṣepọ̀ wọn pẹ̀lú Nàìjíríà lójú ju ti tẹ́lẹ̀ lọ. Bákan náà ni ó jẹ́ pé a nílò láti kọ biara sí ṣíṣe ògbifọ́ àwọn lítíréọ̀ alohùn Yorùbá sí àwọn èdè Nàìjíríà àti ti ilẹ̀ Afíríkà míràn. Èyí yóò fi àyè sílẹ̀ fún ìgbọ́ra-ẹni-yé lẹ́yìnọ̀rẹyìn. Ó wà níbàámu pẹ̀lú ìlànà ètò ẹ̀kọ́ ilẹ̀ Nàìjíríà kò sì lodì sí ìlànà àgbékalẹ̀ ètò ẹ̀kọ́àti ìbáṣepọ̀ Àjọ Ìṣọ̀kan Áfíríkà.

## 4.3 Ṣíṣe Ìtúpalẹ̀

Ohun pàtàkì tí a níláti rán wa létí kí á sì fi sọ́kàn nípa ṣíṣe ìtúpalẹ̀ tí ó dáńgájía fún lítíréṣọ̀ alohùn tí a ti dàkọ ni pé bí ó tilẹ̀ ti wá di kíkọ sílẹ̀ báyìí, èyí kò sọ ọ́ di àpilẹ̀kọ. Má-yà-mí ni lítíréṣọ̀ alohùn àti ọ̀gangan ipò rẹ̀ bí a ti sọ ṣaájú. Nínú ṣíṣe ìtúpalẹ̀ tí ó múná dóko, a gbọ́dọ̀ fi eléyìí sọ́kàn. Olùwádìí gbọ́dọ̀ ní òye kíkún nípa gbogbo àṣà tí ó rọ̀ mọ́ iṣẹ́ ọnà ẹnu tí ó ń ṣiṣẹ́ lé lórí, kí ó sì mọ gbogbo ohun tí ó ṣẹlẹ̀ lójú agbo eré níbi tí ó ti gba ohùn tí ó dàkọ. Nínú iṣẹ́ ìtúpalẹ̀ yí ni yóò tí nílò àwọn fọ́tò àti fídíò tí ó yà ní oko ìwádìí lati fìdí àwọn ìtúpalẹ̀ àti alàyé rẹ̀ múlẹ̀.

### 4.3.1 Àmúlò Tíọ̀rì

Ṣiṣe ìmúlò tíọ̀rì fún iṣẹ́ ìtúpalẹ̀ ti wá di ohun tí ó pọn dandan lóde òní. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àyè wà fún ṣiṣe ìtúpalẹ̀ àlápèjúwe, síbẹ̀ a nílò láti ṣe àtúpalẹ̀ tí yóò wa gbòǹgbò ọ̀rọ̀ délẹ̀, tí a óò fi mọ ìdáhùn sí gbogbo ìbéèrè tí ó jẹ mọ́ ìdí tí gbogbo ohun tí a ṣàkíyèsí fi rí bẹ́ẹ̀ àti ọ̀nà tí wọ́n gbà rí bẹ́ẹ̀. Àwọn onímọ̀ ìṣaájú ti fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà wí pé ẹyọ tíọ́rì kan ṣoṣo kì í kógo já fún ṣíṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ ilẹ̀ Áfíríkà. Wọ́n ti dábàá pé ìmúlò àkànpọ̀ oríṣìírísìí tíọ́rì ni yóò wúlò fún ṣíṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ Afíríkà.

Emenanjo(2000) ti pe àkíyèsí sí àwọn ìlànà tíọ́rì méjìlá tí ó ní Dundes (1975) sọ pé a lè múlò nínú iṣẹ́ ìwádìí nípa lítíréṣọ̀ alohùn ilẹ̀ Áfíríkà. Nítorí pé ṣíṣe ìtúpalẹ̀ ṣàn-án ni ó kàn wá gbọngbọn ní ìhín àti pàápàá fún ìrọ̀rùn wa nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ọ̀nà méjì péré ni a óò pín gbogbo àwọn tíọ̀rì náà sí. Àkọ́kọ́ ni àwọn èyí tí ó wùlò fún ṣíṣe ìtúpalẹ̀ alápèjúwe, ìkejì sì ni èyí ti ó wúlò fún ṣiṣe àwàkànlẹ̀ ìtúpalẹ̀ lórí àwọn bátàni ti a kíyèsí nínú ìtúpalẹ̀ alápèjúwe tí a bá ṣe. Ní tí àkọ́kọ́ ni àwọn tíọ́rì ajẹ-mọ́fojú-ààtò-wò pọ̀ mọ́ tajẹ-mọ́fójú-ìhun-wò nínú èyí tí ti ajẹmọ́fọ́múlà náà wà. Àwọn tíọ́rì ti ọ̀nà kejì ni tíọ́rì ajẹmọ́ ìwúlò/ ìṣàmú-lò ńǹkan, tíọ̀rì

ajẹmọ́mọ̀-ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi/ orírun àti ìtàn-káàkiri agbègbè, tíọ̀rì máàsì, tíọ̀rì ajẹmọ́rònú ọkàn, tíọ̀rì ajẹ-mọ́gangan-ipò àti tíọ̀rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò. Gbogbo àwọn tíọ̀rì kejì yí ni ó ní ohun kan tàbí òmíràn án ṣe pẹ̀lú ìbágbépọ̀ láwùjọ. Ohun kan tí a gbọ́dọ̀ fí sọ́kàn nígbàkúgbà tí a bá fẹ́ yan tíọ̀rì ni pé lítíréṣọ̀ alohùn tí a bá fẹ́ ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀ àti àfojúsùn ìwádìí tí à ń ṣeni yóò ṣe atọ́nà irú tíọrì àmúlò. A kò gbọdọ̀ ra tíọ̀rì tí kò wúlò ní kíkún bọ iṣẹ́ lítíréṣọ̀ alohùn kan lọ́rùn. Ohun mìíràn tí a tún níláti ṣe ni pé a gbọ́dọ̀ ṣe àtún-gbé-yẹ̀wò ìlànà àmúlò tíọ̀rìkítíọ̀rì tí a bá fẹ́ lò dáradára, kí a sì rí i wí pé a ṣàtúnṣe sí i, kí ó lè wúlò daradara fún ìṣàtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn tí a dágbá lé ní pàtó.

## 4.4 Ọ̀rọ̀ Ìṣẹ̀tọ́

Kì í ṣe ní oko ìwádìí nìkan ni ṣíṣẹ̀tọ́ ní ìbámu pẹ̀lú ìwà ọmọlúwàbí tí a mọ àwọn Yorùbá mọ́ ti ṣe pàtàkì, ó ṣe pàtàki lẹ́yìn tí a bá toko ìwádìí dé náà pàápàá, nínú ṣíṣe àkọsílẹ̀ àwọn ìjábọ̀ rẹ. Ní oko ìwádìí a ti sọ pé olùṣewádìí kò gbọdọ̀ gbéraga, ó gbọ́dọ̀ ní sùúrù, ó gbọ́dọ̀ lawọ́, kò gbọdọ̀ yẹ adéhùn, ó gbọ́dọ̀ múra lọ̀nà ti yóò fi jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà lọ́dọ̀ àwọn oní-lítíréṣọ̀ alohùn náà tí wọ́n jẹ́ abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀. Bí kò bá ṣe gbogbo ìwọ̀nyí ó lè má ṣe àṣeyọrí tí ó mọ́yan lórí nínú iṣẹ́ oko ìwàdí. Àwọn onílítíréṣọ̀ alohùn náà lè má dá a lóhùn dáadáa. Kí wọ́n má túraká sí i. Nínú àwọn àkọsílẹ̀ tí olùwadìí bá ṣe lẹ́yìn oko ìwádìí, ó gbọ́dọ̀ ṣe ẹ̀tọ́ sí àwọn abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀ nípa kíkọ orúkọ wọn sí ibi iṣẹ́ náà gẹ́gẹ́ bí onílítíréṣọ̀ náà àti abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀. Gbogbo àwọn tí ó bá fọ̀rọ̀ wá lénu wò náà ni ó gbọ́dọ̀ kọ orúkọ wọn kí o sì dúpẹ́ lọ́wọ́ wọn. Yàtọ̀ sí èyí, ó yẹ kí olùwádì ṣe àkójọpọ̀ orúkọ gbogbo àwọn ẹni tí o gba ọ̀rọ̀ lẹ́nu wọn (abẹ́nà ìmọ̀); ọjọ́ orí wọn, àdírẹ́sì wọn ní kíkún, pàápàá ti ibi tí ó ti gba ohùn sílẹ̀ àti ọjọ́ tí ó gba ọ̀rọ̀ lẹ́nu wọn, kí ó sì fí ṣe àsomọ́ ní ìparí àkọsílẹ̀ ìjábọ̀ ìwádìí rẹ̀. Ohun tí èyí wúlò fún ni bí ẹlòmíràn óò bá fẹ́ lọ ṣe irú ìwádìí bẹ́ẹ̀ lọ́dọ̀ wọn lọ́jọ́ iwájú. Nínú àkọsilẹ̀ àbọ̀ ìwádìí rẹ̀, olùwádìí kò gbọdọ̀ sọ ọ̀rọ̀ ìtàbùkù tàbí ìtẹ́ńbẹ́lú kankan, yálà sí àwọn tí ó lọ gba ọ̀nà ohùn lẹ́nu wọn tàbí nípa ọnà ohùn tí o lọ gbà náà gan-an. Kò sì gbọ́dọ̀ jẹ́ kí èrò ẹ̀sìn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọmọ-lẹ́yìn-Jésù tàbí Mùsùlùmí tàbí èrò ara tirẹ̀ kan tàbí òmíràn nípa tí kò wuyì lórí àkọsílẹ̀ rẹ̀.

## 4.5 Pípadà lọ sí Oko Ìwádìí

Pípadà lọ sí oko ìwádìí láti bèèrè àwọn ohun tí ó bá rúni lójú máa ń wáyé dáradára.Ó kéré tán olùwádìí máa ń nílò láti padà lọ oko ìwádìí lẹ́ẹ̀kan, ó sì lè jù bẹ́ẹ̀ lọ. Nígbà tí olùwádìí bá ń jábọ̀ iṣẹ́ oko ìwádìí àkọ́kọ́ tí ó lọ ni yóò ti máa ṣe àkójọ gbogbo ohun tí ó bá rú u lójú, tí ó sì nílò àlàyé kíkún sí i. Àwọn yìí ni yóò mú padà lọ sí oko ìwádìí láti lọ béèrè fún àlàyé kíkún. Kì í ṣe nítorí ṣíṣe ìdàkọ nìkan ni olùwádìí máa ń nílò láti padà sí oko ìwádìí sí. Nígbà míràńó lè rí i pé àwọn ohùn ọnà ẹnu tí òún gbà sílẹ̀ kò kún tó, tàbí kí ó fẹ́ ṣèwádìí lórí bóyá irú àwọn àpẹẹrẹ kan tí ó fẹṣẹ̀ tíọ̀rì tí ó ń lò múlẹ̀ tàbí tí ó ta kò ó wà tàbí kò sí nínú

lítíréṣọ̀ alohùn náà. Gbogbo irú àwọn ǹǹkan báyìí àti òmíràn bẹ́ẹ̀ ni ó lè gbé olùwádìí padà lọ sóko ìwádìí.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín yìí, a jíròrò nípa àwọn ojúṣe mẹ́ta wọ̀nyí, tí olùwádìí yóò ṣe lẹ́yìn tí ó bá toko ìwádìí dé tán: ṣíṣe ìdàkọ, ṣíṣe iṣẹ́ ògbifọ̀ àti ṣíṣe ìtúpalẹ̀. Lábẹ́ ṣíṣe ìtúpalẹ̀ ni a ti sọ̀rọ̀ nípa ìmúlò tíọ́rì. Ní ìparíparí ni a sì tún ti sọ̀rọ̀ nípa àwọn ìgbésẹ̀ ìṣẹ̀tọ́ tí olùwádìí níláti gbé kí gbogbo akitiyan rẹ̀ lè yanjú.

- A sọ pé aṣàdàkọ yóò nílò láti padà lọ sọ́dọ̀ àwọn onílítíréṣọ̀ alohùn ní oko ìwádìí láti béèrè àwọn ohun tí kò bá gbọ́ dáadáa, lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ àgbọ́túngbọ́túngbọ́, tí ó gba sùúrù àti ẹ̀kún-rẹ́rẹ́ ìfọkàn-sí.
- Ó gbọ́dọ̀ lo àkọtọ́ tí ó súnmọ́ pípe ọ̀rọ̀ lẹ́nu.
- A ní, lílo ìlànà ibi ìdánudúró díẹ̀ nìkan kò tó láti ṣòdiwọ̀n ìlà ewì tí ó bá ń dàkọ. Yóò nílò láti lo ìlànà ìtumọ̀ kíkún papọ̀ mọ́ tí ìbádọgba gbólóhùn ní ọ̀pọ̀ ìgbà.
- A fi yé wa wí pé kí lítíréṣọ̀ alohùn tí à ń kó jọ baà wà ní àrọwọ́tó àwọn elédè míràn ni a fi nílò láti ṣògbifọ̀ rẹ̀. Ohun tí a sì tẹnpẹlẹ mọ́ jù nínú èyí ni pé ìtumọ̀ gbọ́dọ̀ lọ tààrà kí òye rẹ̀ sì pé.
- A tún sọ pé aṣògbifọ̀ nílò láti lo ìtọsẹ̀ ọ̀rọ̀ fún ṣiṣe àlàyé kíkún níbi tí ó bá ti nílò irú àlàyé bẹ́ẹ̀.
- Nípa ṣíṣe iṣẹ́ lámèétọ́, a tẹnu mọ́ ọn pé níwọ̀n ìgbà tí lítíréṣọ̀ alohùn àti ọ̀gangan ipò rẹ̀ kì í ti í ya ara wọn, ẹni tí yóò bá ṣe iṣẹ́ lámèétọ́ gbọ́dọ̀ ní ẹ̀kún rẹ́rẹ́ òye nípa ọ̀gangan ipò náà kí ó sì ṣe àmúlò rẹ̀ ní kíkún nínú iṣẹ́ ìtúpalẹ̀ tí ó ń ṣe.
- Ọ̀nà méjì ni a pín àwọn tíọ́rì tí a lè ṣàmúlò nínú ṣiṣàtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn sí: àwọn ti a lè lò fún ìtúpalẹ̀ àṣàpèjúwe àti àwọn tí a lè lò láti wa gbòǹgbò ọ̀rọ̀ délẹ̀.
- A tọ́ka sí i pé àkànpọ̀ àwọn tíọ́rì wúlò fún ṣiṣe ìtúpalẹ̀, àti pé tíọ̀rì tí à ń lò gbọ́dọ̀ bá lítíréṣọ̀ alohùn tí à ń tú palẹ̀ mu.
- Nínú ọ̀rọ̀ ìṣẹ̀tọ́, a jẹ́ kí ó yéni pé kì í ṣe ní oko ìwádìí nìkan ni ọ̀rọ̀ ìṣẹ̀tọ́ ti ṣe pàtàkì, ó ṣe pàtàkì nínú gbogbo àkọsílẹ̀ náà. A ní gbogbo àwọn tí olùwádìí gba ọnà ohùn lẹnu wọn, àti àwọn tí ó fi ọ̀rọ̀ wá lẹ́nu wò ni ó gbọ́dọ̀ kan sáárá sí kí ó sì ṣe àkọsílẹ̀ kíkún nípa wọn.
- A tún tọ́ka sí i pé olùwádìí kò gbọdọ̀ ṣe àkọsílẹ̀ tí ó lè tàbùkù, àwọn abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀ lọnàkọnà.
- Ní ìparípari a pe àkíyèsí sí i pé kì í ṣe nípa ṣíṣe ìdakọ nìkan ni pípadà lọ oko ìwádìí pọn dandan fún; ó pọn dandán fún àwọn ẹka ìjábọ̀ iṣẹ́ ìwadìí náà mìíràn pẹ̀lú.

Ó hàn gbangba báyìí wí pé iṣẹ́ takuntakun ni olùwádìí ní lati ṣe lẹ́yìn tí ó bá ti oko ìwádìí dé. Bí iṣẹ́ lílọ sí oko ìwádìí ti ṣe pàtàkì nítorí pé òun ni iṣẹ́ ìpìlẹ̀, bí a ṣe sọ, bẹ́ẹ̀ náà ni iṣẹ́ ìdàkọ, ògbifọ̀, àti ìtúpalẹ̀ náà ṣe pàtàkì. Gbogbo àwọn ìgbésẹ̀ inú àwọn iṣẹ́ náà ni ó gba sùúrù, ìfọkànsí tí ó ga, ìforítì àti ìfaradà, tí wọ́n sì jẹ́ ẹlẹgẹ́, tí ó nílò ríronújinlẹ̀ lé lórí gidigidi. Àbájáde rẹ̀ ṣe pàtàkì nínú títọ́ka sí yíyege tàbí àìyege gbogbo iṣẹ́ olùwádìí lápapọ̀. Àbájáde rẹ̀ ni yó jẹ́ àkọsílẹ̀ fún gbogbogbòò lákòókò bágbàmu yìí àti fún ìran tí ń bọ̀. Ìdí nìyí tí iṣẹ́ náà fi jẹ́ ẹlẹgẹ́. Bí ọ̀làjú ti ń gbilẹ̀ sí i ni a rí i pé púpọ̀ nínú àwọn ohun àṣà ìbílẹ̀ wọ̀nyí ń lọ sí okun ìgbàgbé, irú àwọn àkọsílẹ̀ àbọ̀ ìwádìí yìí ni yóò kù ní ẹ̀rí pé àwọn lítíréṣọ̀ alohùn náà ti wà rí nírú ìgbà náà. Ìdí jíjẹ́ ẹlẹgẹ́ iṣẹ́ náà nìyẹn. Olùwádìí kò sì gbọdọ̀ káàrẹ̀ láti padà lọ sí oko ìwádìí fún ṣíṣe ìwádìí kíkún síwájú sí i lórí ohunkóhun tí ó bá ta kókó nígbà tí ó bá ń jábọ̀ iṣẹ́ rẹ̀; èyí lè mú un padà lọ sí oko ìwádí ju ẹ̀ẹ̀kan ṣoṣo lọ.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Kín ni ìṣoro pàtàkì tí ó lè mú kí ṣíṣe ògbifọ̀ lítíréṣọ̀ má já gaara, kín sì ni olùwádìí tó fẹ́ ṣògbifọ̀ níláti ṣe láti borí ìṣoro náà?
2. Ṣe àlàyé ipa ọ̀gangan ipò nínú ṣiṣe ìtúpalẹ̀ láméyítọ́ lítíréṣọ̀ alohùn.
3. Sọ ọ̀nà méjì tí a pín àwọn tíọ̀rì tí a lè lò fún ṣíṣàtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ alohùn sí, sì dárúkọ àwọn tíọ̀rì tí ó wà ní ọ̀nà kọ̀ọ̀kan.
4. Jíròrò lórí ìṣẹ̀tọ́ ní oko ìwádìí àti nínú ìṣàkọsílẹ̀ lẹ́yìn oko ìwádìí.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Abímbọlá, W.1987 “Notes on the Collection, transcription, translation and analysis of Yorùbá Oral Poertry,” nínú Adébísí Afọláyan *Yorùbá Language and Literature*,Uniersity Press Ltd., Ìbàdàn àti University of Ife Press, Ilé Ifẹ̀.

Babalọlá, A. 2001. *Àwọn Oríkì Orílẹ̀ Mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n*. Longman Nigeria Plc.,Lagos.

Dundes, A. 1975 *Analytical Essays in Folklore*, Montane Publishers, New York.

Emenanjo, E. N. (2000) “ the Generic Determination of African Oral Literary Texts” nínú D. Opata àti A. Ohaegbu (olóòtú) *Major Themes in African Literature*, AP Express Publishers, Nsukka.

Ògúndèjì, P.A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. University ofÌbàdàn Centre for External Studies, Ìbàdàn.

Ọlátúnjí, Ọ.Ọ. 1984. *Features of Yorùbá Oral Poetry*. University Press Plc.,Ìbàdàn.

# ÌPÍN 4 ÌPÍNSÍSỌ̀RÍ LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ I: ÀWỌN ÌSỌ̀RÍ ŃLÁŃLÁ

**AKOONU**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Ewì
 4.2 Àròsọ Ọlọ́rọ̀Geere
 4.3 Eré Oníṣe
 4.4 Ìwọ̀n
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Bí a bá bẹ̀rẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín kẹrin yìí pẹ̀lú ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ Yorùbá tí ó sọ pé, "Kó sí bí ọ̀bọ ṣe ṣorí tí ìnàkí kò ṣe" tàbí "Kò síbi tí a kì í ti í kó ádìẹ alẹ́", kò léèwọ̀. Ìdí ni pé káàkiri àgbáńlá ayé ni wọn ti máa ń pín lítíréṣọ̀ sí ìsọ̀rí méta tí a fẹ́ jíròrò lé lórí ní ìhín. Àwọn ìsọ̀rí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta náà ni ewì, ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere àti eré oníṣe. Ìdí sì nìyí tí a fi pe ìpínsísọ̀rí náà ní ti kárí ayé (Ògúndèjì 1991). Ohun mìíràn ti a óò tún mẹ́nu bà kí a tó lọ sínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wa náà ni pé àwọn onímọ̀ ìṣaájú ti ṣiṣẹ́ púpọ̀ lórí ewì àti ìtan àròsọ ọlọ́rọ̀ geere nítorí pé ó rọrùn láti ṣe ìdakọ wọn ju ti eré oníṣe lọ. Bí àwọn kan bá tilẹ̀ ń sọ̀rọ̀ lítíreṣọ̀ alohùn wọn kì í sọ̀rọ̀ nípa ere oníṣe rárá; wọn kì í tilẹ̀ mẹ́nu ba eré oníṣe alohùn, àwọn kan tí wọ́n sì mẹ́nu bà á kò ṣe àlàyé lórí rẹ̀ tó bí ó ti yẹ. Lára ohun tí ó lè fa èyí ni pé àti ewì àti ọ̀rọ̀ geere máa ń péjú pésẹ̀ nínú eré oníṣe. Ohun kan tí ó ṣe pàtàkì kí á tún rán ara wa létí ni pé lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá àti tilẹ̀ Áfíríkà lápapọ̀ kò ṣe é yà kúrò lára ọ̀gangan ipò/ àyíká àti àwùjọ rẹ̀. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pe tíọ̀rì ìfojú-ìwúlò-wò, tàbí tìfojú ìbáṣepọ̀-láwùjọ-wò ni ó ní í ṣe pẹ̀lú lítíréṣọ̀ alohùn wa ju ti ìfojú-ètò-wò tàbí tìfojú-ìhun-wò lọ.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀÀTI AFOJÚSÙN

Ní ìparí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó ti lè jíròrò lórí àwọn àbudá tí ó mú àwọn ìsọ̀rí ńláńlá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta (ewì, ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀geere àti eré oníṣe) tí lítíréṣọ̀ alohùn pín sí yàtọ̀ síra wọn àti àwọn ọ̀nà tí wọ́n gbà wọnú ara wọn.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Kín ni àwọn àbùdá mẹ́ta pàtàkì ewì?
2. Irú ìwọ́hùn àti ìwéhùn wo niìtan àròsọ ọlọ́rọ̀ geere ní tí ó yàtọ̀ sí ti ewì?
3. Ǹjẹ́ ohun tí a lè pè ní eré oníṣe alohùn Yorùbá wà bí? Ṣàlàyé èrò rẹ pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ewì

Ọ̀jọ̀gbọ́n Yẹ́misí Adébọ̀wálé (2017) ti ṣe àgbéyẹ̀wò oríkì tí àwọn onímọ̀ fún ewì. Ohun tí àwọn onímọ̀ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin (Akinjógbìn 1969, Ọlátunjí 1984, Adébọ̀wálé 1999 àti Adágbádá 2008) tí Àdébọ̀wálé gbé yẹ̀ wò, fẹnu kò sí ní ṣókí, ni pé àmúlò èdè ewì a máa ní àdùn tí ó peléke. Ohun tí ó ń fa adùn èdè yìí ni àmúlò àwọn "... àṣàyàn ọ̀rọ̀ tí..." akéwì máa ń "... mọ̀-ọ́n-mọ̀ tò pọ̀..." (Adébọ̀wálé 1999: 54), nínú èyí tí ìmúlò ọnà èdè ṣe kókó. Àwọn àṣàlò ọ̀rọ̀ pọ̀ mọ́ ọnà èdè tí a fi ọgbọ́n ajẹmọ́nà ṣètò ìgbékalẹ̀ rẹ̀ yìí ni ó máá ń jẹ́ kí kókó ọ̀rọ̀ tí a ń fi ewì gbé kalẹ̀ múni lọ́kàn.

Àbùdá méjì pàtàkì ewì tí a lè rí fà yọ nínú àlàyé yìí ni ìmúlò èdè dídùn àti ètò ajẹmọ́nà. Àbùdá kẹta, ìyẹn èrò tí ó múni lọkàn súyọ láti inú méjì tí akọ́kọ́ mẹ́nu bà. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ọnà èdè, àti ọnà ìró náà, ni ó máa ń mú kí ẹwà tàbí adùn hàn nínú ewì. Ní àfikún sí èyí, ètò ajẹmọ́nà inú ewì náà a máa jẹ́ kí ewì ní ìwọ́hùn tí ó fani mọra. Èyí náà a sì máa ń mú kí ẹwà/ adùn ewì ó fara hàn. Àpapọ̀ gbogo ìwọ̀nyí ni kì í mú olùgbọ́ ewì gbàgbé rẹ̀ fún ìgbà pípẹ́ lẹ́yìn tí ó ti gbọ́ ọ. O yẹ kí á tún yán an dáradára pé bí a ti lè fi ìlànà ìwọ́hùn àti ìwéhùn ìṣàré, sẹ ìgbékalẹ̀ ewì alohùn Yorùbá náà ni a lè lo ti orin kíkọ tàbí ti ọ̀rọ̀ sísọ. A óò túbọ̀ máa pààlà sáàrin ọnà ìgbéwìkalẹ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó kàrùn-ún.

Ohun tí a fí ń ṣèdámọ̀ ewì nígbà tí a bá kọ ọ́ sínú ìwé ni pé abala ojú ìwé ni a máa ń kọ ọ́ sí ní ìbámú pẹ̀lú ìlànà ìṣọwọ́kọ ewì. A kì í kọ ọ́ kún gbogbo ojú ìwé bí i ti ọ̀rọ̀ geere. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ tẹ́lẹ̀ ìlànà onílàjilà ni a fi máa ń kọ ọ́, kì í ṣe ti ọlọ́rọ̀ geere. Ẹ jẹ́ kí a wo àwọn àpẹẹrẹ àwọn àdàkọ ewì wọ̀nyí:

Àpẹẹrẹ 1.

Jíjí tí mo jí n ò gbọ́ poroporo odó
Ọ̀gànjọ́ gàn n ò gbọ́ wọ̀ṣọ̀wọ̀ṣọ̀ kọ̀ǹkọ̀ṣọ̀
N ò gbọ́ ṣin-inrinkúnṣin ká dín eku mẹ́ja
Àfàìmọ̀ káwo má sùn lébi
Àfàìmọ̀! (Akínjógbìn 1969)

Àpẹẹrẹ 2. Òtítọ́ dọ́jà, ó kùtà
Owó ńláńlá là ń rèké
Báráyé bá róníró̩
Wọn a tẹ́ní ẹwẹlẹ fún un (Ògúndèjì 2013: 98)

Àpẹẹrẹ 3. Ọ̀kan ṣoṣo póro lobìnrinín dùn mọ lọ́wọ́ ọkọ.
Bíwọ́n bá di méjì,
Wọ́n a dòjòwú.
Bí wọ́n bá di mẹ́ta,
Wọn a dẹ̀taǹtúlé.
Bí wọ́n bá di mẹ́rin,
Wọn a dìwọ lo rín mi ni mo rín ọ.
Bí wọ́n bá di márùn-ún,
Wọn a di lágbájá ni ó run ọkọ wa tán lóhun susùùsu.
Bí wọ́n bá di mẹ́fà,
Wọn a dìkà.
Bí wọ́n bá di méje,
Wọn a dàjẹ́.
Bí wọ́n bá di mẹ́jọ,
Wọn a dìyá alátàrí bàǹbà ló ti kóirú èyí ṣẹ ọkọ wa lọ́wọ́
Bí wọ́n bá di mẹ́sàn-án,
Wọn a di ìyáálé wa ò nísẹ́ kan,
Kò lábọ̀ kan, bó bá ti jí
Aṣọ ọkọ wa níí máa sán kiri
Bí wọ́n bá di mẹ́wàá

Wọn a di ilé lọkọ wa jókòó
Ni wọ́n ń wá ọkọ wa á wá. (Abímbọ́lá, 2006: 29 – 30)

Àmúlò èdè àti ètò inú àwọn àyọlò mẹ́tẹ̀ẹ̀ta òkè yìí ló mú kí wọ́n jẹ́ ewì. Nínú àpẹẹrẹ 1 àwọn ọ̀rọ̀ ìfìròó-sínròó-jẹ bí i “poroporo”, “wọ̀ṣọ̀wọ̀ṣọ̀” àti “ṣin-in-rin-kún-ṣin-kún” ràn wá lọ́wọ́ láti ní òye kíkún nípa dídún odó nígbà tí wọ́n bá ń gúnyán, dídún kọ̀ǹkọ̀ṣọ̀ tàbí ajọ̀ nígbà tí wọ́n bá ń jọ èlùbọ́ àti dídún ẹja àti eku nígbà tí wọ́n bá ń dín wọn. Ọ̀pọ̀ ọmọ òde òní ni kò le tètè mọ ìtumọ̀ kọ̀ǹkọ̀ṣọ̀ tí a mẹnu bà lẹ́ẹ̀kan nítorí irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ti ń di ọ̀rọ̀ ìkàsì. A lè sọ wí pé ọnà ajẹmọ́ròó ohùn ni ẹwà adùn ewì náà gùn le. Nínú ewì 2, àkàwé ọ̀rọ̀ tí ó jẹmàfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ̀ ni a fi ṣàgbékalẹ̀ ìjinlẹ̀ ọ̀rọ̀ nípa òtítọ́ àti èké. A ṣàgbékalẹ̀ àwọn iwà méjèèjì bí ẹni pé ọjà títà ni wọn. Nínú ìlà àkọ́kọ́ àti èkejì ni a ti fi yé wa pé òtitọ kì í tà, nígbà tí ó jẹ́ pé wìtìwìtì ni wọ́n máa ń du èké rà, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó wọ́n gógóógó.

Àsọdùn tí ó forí mù nínú àwọn ìlà méjì àkọ́kọ́ yìí ni ó wá han gbngba nínú àwọn ìlà méjì yòókù, níbi tí akéwì ti fi ọ̀rọ̀ ya àwòrán bí àwọn

ènìyàn ṣe máa ń ṣe àpọ́nlé ẹni tí ó bá ń ṣèké. Títẹ́ní ẹwẹlẹ fún oníró̩ ti ó sọ ni ó fi ṣàgbékalẹ̀ àkàwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ àti alásọdùn náà. Ọnà èdè tí ó hànde jùlọ nínú àpẹẹrẹ 3 ni ìfọ̀rọ̀dárà ìró àwọn òǹkà Yorùbá láti méjì dé orí mẹ́wàá. Bí o bá wo àwọn ìró sílébù tí a kọ gòdògbò nínú ewì náà, o ó ṣe àkíyèsí pé wí pé àwọn sílébù inú yálà ọ̀rọ̀ ìṣe tàbí ti ọ̀rọ̀ orúkọ tí a ṣẹ̀dá, tí ó wà nípò àbọ̀ yẹn fara jọ sílébù tí ó kẹ́yìn nínú òǹkà ọ̀rọ̀ orúkọ òǹkà kọ̀ọ̀kan.

Yàtọ̀ sí èyí, a ṣàkíyèsí wí pé àyọlò lóri àwítúnwí alákùdé gbólóhùn, tàbí kí a kúkú sọ pé ìbádọ́gba gbólóhùn ni ètò ewì 3 gùn lé. Férémù gbólóhùn tí ó la àyọlò ewì náà já látòkè délẹ̀ ni ti

#Bí wọ́n bá di ---,
Wọn a di ---.#

Èyí wà lára àwọn ọgbọ́n àmúni-tètè-níran/ranti tí àwọn akéwì alohùn Yorùbá máa ń lò. Bí ète yìí ti máa ń mú akéwì tètè rántí ohún tí yóò sọ náà ni kò níí jẹ́ kí olùgbọ́ ewì náà ó tètè gbàgbé ohun tí ó ti gbọ́ fún ìgbà pípẹ́. Ọgbọ́n yìí fi àyè sílẹ̀ láti ṣe ẹ̀kàrikà. Àti ìfọ̀rọ̀ gbe ọ̀rọ̀ pàápàá. Nípa bẹ́ẹ̀ ni a sì ṣe rí i pé òye ọ̀rọ̀ kan náà ni akewì ń tẹnu mọ́ ní oríṣiríṣi ọ̀nà. Àwítúnwí ibẹ̀ sì nípa lórí ìwọ́hùn àyọlò ewì náà pẹ̀lú. Irú ìbádọ́gba gbólóhùn yìí náà tún fara hàn nínú àyọlò 1. Férémù gbólóhùn tí ó wà nínú ìbádọ́gba gbólọhùn ìlà mẹ́ta àkọ́kọ́ ni: #--- n ò gbọ́ --- #. Àkókò ni àpòlà ọ̀rọ̀ orúkọ tí ó wà ní ipò ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn kọ̀ọ̀kan ń fi hàn. Nígbà tí akéwì jí, ìyẹn ní àárọ̀ kùtùkùtù ni ti àkọ́kọ́. Nígbà tí òòrùn kan àtàrí, ní ọ̀sán ganrínganrín ni ti ilà kejì, ọ̀sán yìí kan náà ni ti ìlà kẹta, bí a kò tilẹ̀ tún un sọ. Òye kan náà ni àwọn àpólà orúkọ tí ó wà nípárí àwọn ìlà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí ń tẹnu mọ́. Ìyẹn ni pé kò sí pé ẹnìkankan ń dáná oúnjẹ láàrọ̀ àti lọ́sàn-án. Ọ̀nà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó gbà sọ ohun kan náà yìí. Ìlà kẹrin ni akéwì ti wá ṣe àwàgúnlẹ̀ ọ̀rọ̀ rẹ̀ tí ó ti fi ìpayà rẹ̀ hàn pé bóyá ni kì í ṣe pé ebi ni yóò pa òun sùn ní ọjọ́ náà. ṣùgbọ́n ọ̀nà tí ó gbà gbé e kalẹ̀ múni lọ́kàn gírígíri, pàápàá tí a bá wo àsọtunsọ ẹyọ ọ̀rọ̀ “àfàìmọ̀” inú ìlà ìgbẹ̀yìn àyọlò ewì náà.

## 4.2 Àrosọ Ọlọ́rọ̀Geere

Ìwọ́hùn àti ìwéhùn ìsọ̀rọ̀ ojoojúmọ́ ni a fi máa ń ṣàgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ geere. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé (ìtàn) àròsọ ọlọ́rọ̀ geere náà lè ṣàmúlò àwọn ọnà èdè tí yóò mú kí ìlò èdè rẹ̀ dùn mọ́ni tàbí kí ó rẹwà, irú àmúlò bẹ́ẹ̀ kì í kún tàbí kí ó peléke tó tí ewi, bẹ́ẹ̀ sì ni ètò ìwọ́hùn rẹ̀ kì í gún régé tàbí kí ìwọ́hùn rẹ̀ ó ṣe wẹ́kú tó ti ewì. Kìí ṣe ìlànà ìjẹméwì tàbí ti onílàjilà ni a fi máa ń kọ ọ́, àkọkún ojú ìwé ni a sì máa ń kọ ọ́, nígbà tí a bá ń kọ ọ́ sílẹ̀ nínú ìwé. Bí àpẹẹrẹ, àwon ohun tí a fi ewì gbé kalẹ̀ nínú àwọn àpẹẹrẹ tí a ṣe ní òkè yẹn lè lọ bí a ti kọ ọ́ ní ìsàlẹ̀ yìí tí a bá fi ọ̀rọ̀ geere gbé e kalẹ̀.

Àpẹẹrẹ 1. Ní àfẹ̀mọ́júmọ́ tí mó jí, n ò gbúròó pé ẹnikẹ́ní ń gúnyán, nígbà tí ọjọ́tún kanrí, n ò gbúròó pé wọn ń kù èlùbọ́, bẹ́ẹ̀ ni wọn ò máa dín eku àti ẹja.
Ṣèèṣì ni pé ebi kọ́ ni yóò lu olúwarẹ̀ pa ṣúlẹ̀ òní báyìí.

Àpẹẹrẹ 2. Bí a bá gbé òtítọ́ dé ọjà fún títà, a kò ní rí ẹnìkankán rà á. Bẹ́ẹ̀ owó gọbọi ní a sì máa ń kó lérí ọjà ẹ̀tàn. Ẹni tó bá ń purọ́ tanni jẹ ni àwọn ènìyàn máa ń pọ́n lé.

Àpẹẹrẹ 3. Ìyàwó kan ṣoṣo péré ni ọkùnrin tí ó bá fẹ́ gbádùn aya yóò fẹ́. Bí ó bá fẹ́ méjì, wọn ó máa bára wọn jà, bí ó bá fẹ́ mẹ́ta, wọn ó tú ẹbí ká, bí ó bá fẹ́ mẹ́rin wọn óò máa fi ara wọn ṣe ẹlẹ́yà, bí ó bá fẹ́ márùn-ún, wọn óò máa fura síra wọn, pé ẹnìkan ni ó fẹ́ run ogún ọkọ wọn, bí ọ bá fẹ́ mẹ́fà, wọn ó máa ṣera wọn níkà, bí ó bá fẹ́ méje wọn ó máa múra wọn lájẹ̀ẹ́, bí o bá fẹ́ mẹ́sàn-án wọn a máa dẹ́yẹ síyàálé wọn nítorí ó ró aṣọ ọkọ wọn mọ́ra káàkiri ilé, bí ó bá sì fẹ́ mẹ́wàá, wọn á máa sowọ́ pọ̀ láti gbógun ti ọkọ wọn nítorí oju tuntun ti ń wá a wá sílé.

Kò sí àní-àní wí pé òye kan náà tí ó wà nínú àwọn ewì mẹ́tẹ̀ẹ̀ta òkè yẹn náà ni a tún fi ìlànà ọ̀rọ̀ wuuru gbé kalẹ̀ yìí. Àwọn àbùdá ẹwà tí ó jẹ mọ́ ọnà èdè àti ètò ti dín kù jọjọ, bẹ́ẹ̀ sì ni kíkọ ni a kọ ọ́ kún gbogbo ojú àyè tí a yà sọ́tọ̀ fún ìkọ̀wé.

## 4.3 Eré Oníṣe

Gẹ́gẹ́ bí a ti pe àkíyèsí sí i tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀, ní ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ lámèétọ́ ṣíṣe lórí lítíréṣọ̀ Yorùbá ní pàtó, àti ti ilẹ̀ Afíríkà lápapọ̀, àwọn onímọ̀ kì í sábà sọ̀rọ̀ nípa eré oníṣe alohùn. Lára ohun tí ó fa èyí ni pé àwọn ìsọ̀rí ńláńlá méjì àkọ́kọ́ yẹn ni ó lọ̀ọ̀rìn, tí ó sì ṣe pàtàkì jù lọ nínú lítíréṣọ̀. Méjèèjì yìí ni ó sì lè fara hàn nínú eré oníṣeí a ti tọ́ka sí tẹ́lẹ̀ . Àbúdá mẹ́ta pàtàkì ni wọ́n máa ń tẹnu mọ́ nínú ṣíṣe ìdámọ̀ eré oníṣe. Àkọ́kọ́ ni ìsínjẹ tí ọ̀pọ̀ gbà pé ó ṣe pàtàkì jù lọ, tí gbogbo àbùdà yòókù sì rọ̀ mọ́. Àbùdá kejì tí àwọn afojú-ìmọ̀-Yúróòpù-wo-ọ̀rọ̀ tún máa ń dúnnu mọ́ gidigidi ni ìsọ̀rọ̀ngbèsì, ìkẹta sì ni àhunpọ̀ ìtàn. Gẹ́gẹ́bí a ti pe àkíyèsí sí i tẹ́lẹ̀, àtìsọ̀rọ̀ngbèsì àtàhunpọ̀ ìtàn pẹ̀lú àwọn àbùdá ìṣere oníṣe mìíràn bíi òṣèré, ẹ̀dá ìtàn, àhunpọ̀ ìtàn, ibùdó ìtan, ibi ìṣeré, òǹwòran, aṣọeré, àwọn ohun èlòìléwọ́ àti torí ìtàgé, ìbòjú, ìfarasọ̀rọ̀, ìlù, orin, ijó, ìṣàré abbl. ni wọ́n níí ṣe pẹ̀lú ìsínjẹ lọ́nà kan tàbí òmíràn.

Nítorí ojú àṣà ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà ni àwọn ónímọ̀ Yúróòpù àti ẹlẹgbẹ́ wọn mìíràn fi máa ń wo lítíréṣọ̀, tí ó sì jẹ́ pé ìsọ̀rọ̀ngbèsì ni ó ń jẹ́ kíkọ sílẹ̀ sínú ìwé ni wọ́n fi tẹnpẹlẹ mọ́ ọn fún ìdámọ̀ eré oníṣe ju àwọn àbùdá yòókù lọ. Ohun tí à ń pe àkíyèsí sí ní ìhín ni pé bátànì ìsọ̀rọ̀ngbèsì ni wọ́n fi máa ń kọ eré oníṣe sílẹ̀ sínú ìwé. Nípasẹ̀ àtòpọ̀ àwọn ìsọ̀rọ̀ngbèsì

wọ̀nyí ni àhunpọ̀ ìtàn, tí wọ́n tún máa ń fúnka mọ́, ti wá máa jẹ yọ (Ọla Rótìmí 1971).

Gẹ́gẹ́ bí àwọn onímọ̀ kan tí wọ́n jẹ́ ọmọ bíbí ilẹ̀ Áfíríkà ti fi hàn, a kò lè fúnka mọ́ ọ̀rọ̀ ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì àti àhunpọ̀ ìtàn fún ṣíṣèdàmọ̀ eré oníṣe àbáláyé ilẹ̀ Áfíríkà. Ìdí ni pé àfihàn àwọn àbùdá méjì wọ̀nyí kò lọ́ọ̀rìn tó bẹ́ẹ̀ jù bẹ́ẹ̀ lọ nínú àwọn eré oníṣe alohùn wa. Kò sí ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì rẹpẹẹrẹ nínú àwọn eré oníṣe ìbílẹ̀ yìí. Kì í sì í sábà sí àhunpọ̀ ìtàn tí ó lọ tààrà, lábala-lábala ni wọ́n máa ń sábà jẹ́. Ìlò ijó, ìfarasọ̀rọ̀, ìmúra àti ìlò àmì lápapọ̀ ni wọn sì máa ń fi ṣàgbékalẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn lọ́pọ̀ ìgbà. Àpẹẹrẹ àwọn onímọ̀ tí ó fara mọ́ irú èrò yìí ni Oyin Ògúnbà, J. A. Adédèjì, Benedict Ìbítókun, N. Ugonna, O. E. Enekwe,P. A. Ògúndèjì,abbl.

Àwọn onímọ̀ wọ̀nyí àti ẹlẹgbẹ́ wọn mìíràn gbà pé nínú orò ajẹmẹ́sìn àti ìgbàgbọ́, ọdún ìbílẹ̀ pẹ̀lú ìṣeré eégún aláré, ní pàtàkì, ni a ti lè rí ohun tí a lè pè ní eré oníṣe Yorùbá. Nínú àwọn yìí ni wọ́n gbà pé ìsínjẹ tí ó jẹ́ àbùdá pàtàkì jùlọ eré oníṣe ti peléke tàbí tí ó ti hàn gbangba jù lọ. Ìwọ̀nba ni ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì tí ń bẹ nínú wọn máa ń mọ. Orin, ìṣàré, ìlù, àtijó, pẹ̀lú àwọn àbùdá ìsínjẹ yòókù ni wọ́n máa ń kópa ìbánisọ̀rọ̀ ní kíkún, yálà láàrin àwọn òṣeré sí òṣèré ní àkókò ìṣeré tàbí láàrín àwọn òṣèré lápá kan àti òǹwòran lápá kejì. Ìpapadà àti ìfiwàwẹ̀dá jẹ àbùdá pàtàkì tí ó tún máa ń hànde nínú àwọn eré oníṣe ìbílẹ̀ wọ̀nyí nítorí pé wọ́n máa ń tẹnpẹlẹ mọ́ ìṣàfihàn oríṣiríṣi ẹ̀dá ìtàn bí àwọn òrìṣà, àwọn babańla àti àwọn akọni pẹ̀lú àwọn ẹ̀dá mìíràn tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìtàn àwùjọ wọn láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ pẹ̀lú. Wọn a sì tún máa ṣe àfihàn àwọn ẹ̀dá ìtàn bágbàmu nàà pẹ̀lú.Gẹ́gẹ́ bí a ṣe yán an wọn kì í sábà fi eré oníṣe alohùn Yorùbá ṣe àgbé kalẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn rẹpẹẹrẹ.

## 4.4 Ìwọ̀núbọ̀nú

Bí a bá wo àwọn ohun tí a ti sọ lókè dáradára, a kò lè má ṣàìṣe àkíyèsí pé àwọn ìsọ̀rí ńláńlá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí a gbé yẹ̀ wò wọnú ara wọn púpọ̀púpọ̀. Ìṣeré tí gbogbo wọn jẹ́, tí ó jẹ́ pé gbígbé kalẹ̀ ní ojú agbo eré/ ibi ìṣeré ni a ti máa ń gbé wọn kalẹ̀, wà lára ohun tí ó fi àyè sílẹ̀ fún ìwọ̀núbọ̀nú tí ó peléke nàà. Gbogbo àwọn ìsọ̀rí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ni ó ń ṣe ìmúlò ìsínjẹ, tí ó jẹ́ àbùdá pàtàkì eré oníṣe. Ohun tí èyí ń tọ́ka sí ni pé eré oníṣe ń fara hàn nínú àgbékalẹ̀ ewì àti ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ wuuru Bí èyí tilẹ̀ rí bẹ́ẹ̀ àwọn àbùdá ìṣeré yẹn kàn wà láti ṣe ìgbékalẹ̀ yálà ewì tàbí ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ wuuru bẹ́ẹ̀ ni. Wọn kì í ṣe ohun àkọ́kọ́ níbẹ̀, ipò ibìkejì ni wọ́n kó nínú ewì àti àròsọ ọlọ́rọ̀ wuuru. Ṣùgbọ́n nínú ìṣeré oníṣe àbáláyé, ipò àkọ́kọ́ ni àwọn àbùdá ìsínjẹ yóò kó.

Bí a bá ń ṣàgbékalẹ̀ àwọn ewì alohùn Yorùbá kan, bí i ìjálá, ìyẹ̀rẹ̀ ìfá sísun, tàbí ẹ̀sà egúngún pípè, ìtàn sísọ a máa wáyé nínú wọn. Ìyẹn ni pé a lè fi àwọn ewì nàà gbé ìtàn kalẹ̀. Bákan nàà ni ó jẹ́ pé ọ̀pọ̀ àwọn ìṣeré orò, ọdún ìbílẹ̀ tàbí ti eegún aláré nàà máa ń tọ́ka sí ìtàn kan tàbí òmíràn.

Ní àfikún bí a bá ń pàlọ́ onítàn orin tí ó jẹ́ irúfẹ́ ewì kan a máa jẹyọ nínú púpọ̀ irú àlọ́ onítàn bẹ́ẹ̀. Ìdí nìyí tí wọn fi máa ń pè àwọn irú èyí tí orín ti ń jẹyọ ní àlọ́ àpagbè. Nínú ìgbé-kalẹ̀ ẹsẹ ifá,àtewì, àti ọ̀rọ̀ wuuru ni púpọ̀ àwọn awo tí ń kifá fi máa ń ṣàgbékalẹ̀ rẹ̀. Ibi ìfáárà rẹ̀ sabà máa ń jẹ́ ewì, kíkì ni wọ́n máa ń kì í. Ọ̀rọ̀ geere ni wọ́n fi máa ń gbé ìtàn àti àlàyé rẹ̀ kalẹ̀ nítirẹ̀. Wọ́n tún lè fi ifá kíkì àti orin ifá kádìí rẹ̀ nílẹ̀. Àpẹẹrẹ àwọn ìwé ifá tí wọ́n fi ìlànà yìí kọ ni *Ojú Ọ̀ṣùpáApá kìnínní àti Apá Kejì*, tí Yémiítàn àti Ogúndélé (1970) kọ, *Ojúlówó Oríkì Ifá(Apá kìíní)* tí àgbà Awo, Olóyè Fáṣínà Agboọlá (1989) àti àwọn awo ẹgbẹ́ wọn kì, tí a sì kó jọ tí a gbé jáde ní abẹ́ àkóso Ọ̀jọ̀gbọ́n Adébóyè Babalọlá àti Afọlábí Ọlábímtán ti Ẹ̀ka Ìmọ̀ Èdè àti Lítíréṣọ̀ Áfíríkà, Fásitì Èkó. Àpẹẹrẹ mìíràn ni *Ìwé Mímọ́ Ifá: Ẹ̀sìn Àkọ́dá Olódùmarè* tí Ifálérè Ọdẹ́gbèmí Ọdẹ́gbọlá (2014, 2019) kọ.

Bí a bá tun wò ó dáradára àkóónu gbogbo àwọn ìsọ̀rí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta a máa gbẹ́nu lẹ́nu nítorí pé nípa ìrírí ní àwùjọ Yorùbá kan náà ni gbogbo wọn máa ńdá lé. Èrò ìjìnlẹ̀ àti ojú àmúwayé Yorùbá kan náà ní í máa jẹ yọ nínú wọn. Bákan náà sì ni ó jẹ́ pé ọ̀nà kan náà ni àwọn ìsọ̀rí lítíréṣọ̀ náà máa ń gbà wúlò ní àwùjọ. Gbogbo wọn ní í máa dáni lára yá tí wọn sì tún máa ń fi òye kan tàbí òmíràn yéni. Bí a ti rí ewì tí àń lò nídìí òrìṣà (Orìṣà pípè) Yorùbá nínú àwọn ìpohùn ewì Yorùbá náà ni a rí nínú eré oníṣe (eré oníṣe àjẹmorò àti ajẹmọ́dún ìbílẹ̀). Kò sí àní àní kankan wí pé ìwọ̀núbọ̀nú tí ó ga wà ní ààrín àwọn ìsọ̀rí lítíréṣọ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta. Bí ó ti rí jákè jádò àgbáyé nìyẹn. Ìdí nìyí tí àwọn onímọ̀ kan kò fi faramọ́ kí á máa pín lítíréṣọ̀ alohùn sí àwọn ìsọ̀rí ńláńlá mẹ́ta náà mọ́. Bí a ṣe lè wá dá ìsọ̀rí ńlá kan mọ̀ yàtọ̀ ni nípaìpeléke àbùdá ìsọ̀rí náà.Bí ó bá jẹ́ pé àbùdá ewì ni ó peléke tàbí tí ó hàndejù lọ nínú ìgbékalẹ̀ kan ju ti àwọn yòókù lọ ewì ni a óò pe irúfẹ́ àgbékalẹ̀ bẹ́ẹ̀. Bákan náà ni yó sì jẹ́ bí ó bá jẹ́ àbùdá eré oníṣe tàbí ti ọlọ́rọ̀ wuuru ni ó lọ̀ọ̀rìn tàbí tí ó fẹsẹ̀ múlẹ̀ jù lọ, a jẹ́ pé eré oníṣe tàbí ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere ni a óò pè é nìyẹn. Nírú àkókò bẹ́ẹ̀ a jẹ́ pé aṣàgbékalẹ̀ lítíréṣọ̀ náà ṣe àmúlò àwọn àbùdá ìsọ̀rí lítírésọ̀ tí kò lọ̀ọ̀rìn púpọ̀ tàbí tí a kò gbájú mọ́ tó nǹkan láti ṣe ìgbékalẹ̀ èyí tí ó lọ̀ọ̀rìn tàbí tí wọ́n gbájú mọ́ yẹn ni.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí a tiṣe àgbéyẹ̀wò ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin àwọn ìsọ̀rí ńlá ńlá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta (ewì, ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ wuuru àti eré oníṣe) tí a ní a lè pín lítíréṣọ̀ alohùn sí bí wọn ti ń ṣe kárí ayé. A wo ìyàtọ̀ ààrín wọn nípasẹ̀ ìlànà ìlohùn (ìwọ́hùn àti ìwéhùn), nípasẹ̀ dídàkọ sínú ìwé àti nípasẹ̀ àbùdá ajẹmágbékalẹ̀ ètò àti ìhun àkóónú wọn pẹ̀lú ìlò èdè. A wo ìjọra tàbí ìwọ̀núbọ̀nú ààrín wọn náà, a sì rí i pé wọn gbé ẹnu lé ẹnu púpọ̀. Kì í wá ṣe nínú àṣà lítíréṣọ̀ alohùnYorùbá nìkan ni èyí ti rí bẹ́ẹ̀; jákè jádò àgbá-ńlá ayé ni. Ṣùgbọ́n a fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé síbẹ̀-síbẹ̀, kì í jẹ́ ti baba tọmọ kí ó má láàlà. Ìpeléke àbùdá ní a sọ pé a lè fi ṣòdiwọ̀n ìdámọ̀ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan. Ohun kan tí afẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ danindanin nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni pé

àwọn ìsọ̀rí lítíréṣọ̀ ńláńlá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta, (ewì, ìtàn ọlọ́rọ̀ wuuru àti eré oníṣe) ni ó wà nínú àṣà Yorùbá. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ohun tí a yán fẹ́rẹ́ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni yóò túbọ̀ hàn kedere bí a ti ń tẹ̀ síwájú nínú kọ́ọ̀sì yìí.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ní ṣókí, ṣe àlàyé ìyàtọ̀ tí ó wà nínú ṣíṣe ìdàkọ ewì,(ìtàn) àrosọ ọlọ́rọ̀ wuuru àti eré oníṣe sílẹ̀sínú ìwé
2. Àbùdá wo ni ó ṣe pàtàkì jù lọ nínú eré oníṣe, dárúkọ márùn-ún mìíràn tí ó mọ̀.
3. jíròrò lóríọ̀nà mẹ́ta, ó kéré tán, tí àwọn ìsọ̀rí ńlá ńlá lítíréṣọ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta, tí a yẹ̀ wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, gbà wọnúara wọn.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Abímbọ́lá, W. 2006. *Ìjìnlẹ̀ OhùnẸnu Ifá, Apá kìn-ín-ní,*University press Ltd.,Àkọ́- gbéjádé, Collins 1969,Glasgow.

*Abímbọ́lá, W.* 2006. *Ìjìnlẹ̀ OhùnẸnu Ifá,Apá Kejì*, Ìbàdàn: University press Ltd. Àkọ́- gbéjádé ,Collins 1969. Glasgow.

Adágbádá, 2008. "Ojúṣe Àwọn Akéwì nínú Ìṣàkoso Ìjọba Àwarawa,"*Yorùbá Gbòde*: *Jọ́nà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè àti Àṣà Yorùbá, Nigeria.* Fọl. 4, Nọ 3, 143 – 155.

Adébọ̀wálé,O. 1999. *Ọgbọ́n Ònkọ̀wé Alátinúdá,* The Capstone Publishers Ltd.,Lagos.

Adébọ̀wálé,O. 2017. "Àgbéyẹ̀wò Èrò Akéwì Lórí Ewì," nínú Dèjì Médùbí, Débọ̀ Gbádébọ̀ àti Abíọla Bello (olóòtú), *Current Studies in Yorùbá Culture, Language and Literature.*Lagos: Department of Linguistics, Asian and Studies, University of Lagos.

Adédèjì, J. A. 1966 "The Place of Drama in Yoruba Religious Observance" *Odù,* fol. 3, no 1, 83 – 94.

Agboọlá, A. F. 1989. *Ojúlówó Oríkì Ifá*Project Publications Ltd.,Lagos.

Akinjógbiǹ, A. 1969,*Ewì Ìwòyí*, Collins,Glasgow.

Enekwe, O. E. 1987 *Igbo Masks: The Oneness of Ritual and Theatre*Dept. Of Social Development, Youth, Sports and Culture,Lagos..

Ìbítókun,1993 B. M. *Dance as Ritual Drama and Entertainment in the Gelede of Ketu Yorùbá Sub-group in west Africa.: A Study in Traditional African Feminism*, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press Ltd.,Ile Ifẹ̀.

Ògúnbà, O.1978, "Traditional African Festival Drama," nínú Oyin Ògúnbà àti Abíọ́lá Irele*Theatre in Africa*, Ìbàdàn University Press,Ìbàdàn.

Ògúndèjì, P. A. 2000*Ritual asTtheatre, Theatre as Ritual: The Nigerian Experience*, Ìṣẹ̀ṣe Monograph Series, Ìbàdàn cultural Studies Group,Ìbàdàn.

Ogúndélé O. àti Yémiítàn, O.(1970) *Ojú ÒṣùpáApá Kìn-ín-ní* Ìbàdàn: Oxford university Press Ltd.

Ogúndélé, O. àti Yémiítàn, O. (1970) *Ojú Òṣùpá Apá Kejì*, Ìbàdàn: Oxford University Press Ltd.

Ọlátunjí, 1984, *Features of Yorùbá Oral Poetry*, University Press Ltd.,Ibàdàn.

Ọdẹgbọlá,I. O. (2014, 2019) *Ìwé Mímọ́ Ifá: Ẹ̀sìn Àkọ́dáOlódùmarè*, Adéọla Adíjat Fálẹ́yẹ (Olóòtú),Havilah Marchants Nigeria Ltd.,Lagos.

Rótìmí, Ọla 1971. "Traditional Nigerian Theatre," nínú Bruce King, (olóòtú) *Introduction to Nigerian Literature*, 36 – 49, University of Lagos Press,Lagos àti Evans Brothers Ltd. Ibàdàn.

Ugonna, N. 1983 Nmowu: A Dramatic Tradition of the Igbo, Lagos UniversityPress, Lagos.

# ÌPÍN 5 ÌPÍNSÍSỌ̀RÍ LÍTÍRÉṢỌ̀ ALOHÙN YORÙBÁ II: ÀWỌN ÌSỌ̀RÍ KÉÉKÈÈKÉ

## ÀKÓÓNÚ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Ewì
  4.1.1 Àrángbọ́
  4.1.2 Ìṣàré
  4.1.3 Orin
 4.2 Ìtàn Àrosọ Ọlọ́rọ̀ Geere
  4.2.1 Ìtàn Ìwáṣẹ̀
  4.2.2 Ìtàn Akọnikàyéfì
  4.2.3 Àlọ́ Onítàn
 4.3 Eré Oníṣe
  4.3.1 Eré Ọdún Ìbílẹ̀
  4.3.2 Eré Eégún aláré
  4.3.3 Ìwọ̀núbọ̀nú
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasi

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Nínú ìpín karùn-ún módù yìí, ni a ti fẹ́ ṣe àgbéyẹ̀wò tìbú tòòró lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. A óò ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìsọ̀rí kéékèèké tí àwọn ìsọ̀rí ńláńlá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí a ti gbé yẹ̀wò nínú ìpín kẹrin kó sínú.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI AFOJÚSÙN

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, yìí o ó ti lè dárúkọ àwọn ìsọ̀rí kéékèké tí ó wà lábẹ́ ewì, ìtàn àròsọ àti eré oníṣe alohùn Yorùbá. O ó sì ti lè ṣe àlàyé ṣókíṣókí lórí ohun tí ìkọ̀ọ̀kan jẹ́ àti àtúnpínsísọ̀rí wọn.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ya àtẹ onígi fún àtúnpínsísọ̀rí àwọn ìsọ̀rí ńlá ńlá mẹ́tẹ̀ẹ̀ta Lítíréṣọ̀ alohùnYorùbá
2. Ní ṣókí, kin ni ìyàtọ̀ tí ó wà làárín orin, ìsàré àti àrángbọ́.
3. Ṣe àlàyé ìwọnúbọnú tí ówà nínú lílo ìlànà ìjẹmágbègbè àti ìmúlò fún ṣíṣe àtúnpínsísọ̀rí ìṣàré Yorùbá.

# 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 Ewì

Ọ̀nà mẹ́ta ni àwọn onímọ̀ máa ń sábàá pín ewì alohùn Yorùbá sí, tí wọ́n bá fi ìlànà ìjẹmóhùn (ìwéhùn àti ìwọ́hùn) wọn ṣe ìlànà ìtúnpínsísọ̀rí náà. Ìkínní ni àrángbọ́, ìkejì ni ìṣàré ìkẹta sì ni orin. Gẹ́gẹ́ bí Ọlátúnjí (1984) ti sọ bí a bá fi ojú ìwọ́hùn àwọn ìsọ̀rí ewì yìí wò ó a óò rí i pé àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ṣàn wọnú ara wọn ni bá a ti tò wọ́n yẹn. Àrángbọ́ ni ó wà ní apá tàbí igún ìbẹ̀rẹ̀ tí ó ṣàn wọnú ìṣàré, ìṣàré sì ni ó wà láàrin gbùgbùn, tí òun náà wá ṣàn wọnú orin, tí ó wà ní igun ìparí pátápátá. A ti mẹ́nu ba àwọn irúfẹ́ ewì mẹ́tẹ̀ẹ̀ta nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín kẹrin lókè. A óò gbìyànjú láti túbọ̀ gbé wọn yẹ̀wò síwájú sí i ní ìhín kí a lè sọ nípa àwọn ìsọ̀rí ìsọ̀rí àti ẹ̀ka ẹ̀ka tí àwọn onímọ̀ ti pín wọn sí.

### 4.1.1 Àrángbọ́

Ìlànà ìwọ́hùn àtìwéhùn ìsọ̀rọ̀ ojoojúmọ́ ni wọ́n fi máa ń ṣe ìgbékalẹ̀ àwọn ewì àrángbọ́. Ìdí nìyí tí àwọn mìíràn fi máa ń pè é ní ewì ọlọ́rọ̀. Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọlátúndé Ọlátúnjí, tí ó ti ṣe iṣẹ́ takuntakun lórí àwọn ewì inú ìsọ̀rí yìí pè é ní ewì alábùdá tàbí afàbùdá-mọ̀. Ìdí ni pé àwọn ewì tí ó wà nínú ìsọ̀rí ewì yìí ní àwọn àbùdá àdání tí ó jẹ mọ́ ìgbékalẹ̀ ètò àti ìhun wọn, tí ó mú ìkọ̀ọ̀kan wọn yàtọ̀ síra wọn. Orin àti ìṣàré a sì máa ṣe àmúlò wọn. Ìyẹn ni pé púpọ̀ nínú àwọn ewì àrángbọ́ máa ń fara hàn nínú àkóónú orín àti ìṣàré dáadáa. A kì í patẹ́ tàbí kí a lu ìlù tàbí ohun èlò orin mìíràn sí i ní àkókò kan náà tí a bá ṣe ìgbékalẹ̀ ewì àrángbọ́. Ìdí tí a lérò pé èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé ìwọ́hùn ewì náà kì í ṣe wẹ́kú pẹ̀lú ti àtẹ́wọ́ pípa tàbí ohun èlò orin náà rárá. Àwọn ewì mẹ́fà tí ó wà ní ìsọ̀rí yìí ni oríkì, ẹsẹ ifá, ọfọ̀, àrọ̀ ajẹméwì, àlọ́ àpamọ̀ àti òwe.

Ògúndèjì (2000) ti tún ìsọ̀rí yìí pín sí ọ̀nà méjì: àrángbọ́ kíkún tàbí nínlá àti àrángbọ́ kéékèké. Ìlànà irúfẹ́ àwọn aṣàmúlò papọ̀ mọ́ bí àwọn ewì náà ṣe kún tó ni ó lò fún àtúnpínsísọ̀rí náà. Àwọn àgbà ni ó yẹ kí ó jẹ́ aṣàmúlò pàtàkì àrángbọ́ nínlá tàbí kíkún, kí àwọn ọmọdé sì jẹ́ ti àrángbọ́ kéékèké. Àkóónú àràngbọ́ kíkún yẹ kí ó kún dáadáa kí ti kéékèké sì keré tàbí kí ó mọ níba. Oríkì, Ẹsẹ ifá àti ọfọ̀ kújúwọ̀n odiwọ̀n méjèèjì fún àrángbọ́ nínlá tàbí kíkún dáradára, nítorí náà ìsọ̀rí yìí ni a tún wọn pín sí. Àlọ́ àpamọ̀ nìkan ni ó kúnjúwọ̀n àwọn òdiwọ̀n méjèèjì fún ìsọ̀rí àrángbọ́ kéékèké papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà. Àwọn èwe ni aṣàmúlò rẹ̀ pàtàkì jù lọ, àkóónú rẹ̀ sì máa ń mọ níba, kì í kún. Ìlànà òdiwọ̀n ẹyọ kọ̀ọ̀kan ni òwe àti àrọ̀ ajẹméwì kúnjúwọn rẹ̀ ninú méjì. Àkóónú òwe máa ń mọníba, ṣùgbọ́n àwọn àgbà ní í máa ṣàmúlò rẹ̀ jù lọ. Ní ti irú àrọ̀, (èyí tí ó kàn wá gbọ̀ngbọ̀n ní ìhín) àwọn ọmọdé ni ó máa ń ṣàmúlò rẹ̀ jù lọ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àkóónú rẹ̀ a máa kún dáradára. Ó ṣe é ṣe kí á kó àwọn méjèèjì yìí sí ìsọ̀rí mìíràn tí a ó pè ní alágbede méjì. Nítorí kí àwọn ìsọ̀rí tí a tún pín yìí ma baà ju méjì lọ ni a kò fi ṣe èyí. Èrò wa ni pé àìkójúwọ̀n àwọn ìlànà

méjèèjì yìí pàápàá wà lára ohun tí a fi lè sọ pé wọn kò kún tó, kí á sì fi ojú ìsọ̀rí kékeré wò wọ́n nítorí náà.

## 4. 1.2 Ìṣàré

Ohùn pípè tàbí ohùn rírán, tí a tún lè ṣe àpèjúwe gẹ́gẹ́ bí ọ̀fun ṣíṣe ni ìṣàré. Bí àwọn apohùn àbáláyé bá ń ṣeré lójú agbo eré, wọn kì í lùlù tàbí kí wọn lo ohun èlò orin mìíràn pàpọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà mọ́ ìṣàré tí wọ́n ń ṣe lọ́wọ́lọ́wọ́. Bí wọ́n bá sì fẹ́ dárin, tí wọn óò lùlù, tí wọn óò sì jó sí, wọ́n óò dá ìṣàré tí wọ́n ń ṣe dúró ni. Ó ní àwọn ìpèdè tí wọn máa sábàá fi ṣe èyí. Bákan náà ni bí wọ́n bá tún fẹ́ máa bá ìṣàré ti wọn ń ṣe nìṣòó, ó tún ní irú ìpèdè tí wọn yóò fọ̀ láti dá orin àti ijó dúró, kí wọn tó ó tẹ̀ síwàjú. Bí àpẹẹrẹ, bí oníjàálá kan bá fẹ́ dá ìṣàré tí ó ń ṣe dúró, tí ó fẹ́ dárin, ó lè wí pé,

"Ẹ́ẹ́ gberin àbẹ́ẹ̀ gberin ẹlẹ́gbẹ́ ọdẹ"
Àwọn ẹlẹ́gbẹ́ ọdẹ tí ó wà ní ojú agbo eré náà yóò sì dáhùn pé,
"A á gberin, tórí orin tàlùkò bá dá lọmọ rẹ̀ ẹ́ gbè"
Lẹ́yìn náà ni orin ìlù àti ijó yóò bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu.
Bí ó bá sì tún fẹ́ dá orin, ìlù àtijó dúró, tí ó fẹ́ máa sun ìjálá nìṣòó, yóò wí pé:

" Ó tóóóóó..."

Gbogbo wọn ó sì dákẹ́, kí ó tó máa bá ìjálá ti ó fẹ́ sun nìṣòó. Àìṣewẹ́kú dáadáa tó ìwọhùn ìṣàré ṣíṣe, tí wọ́n bá fẹ́ lulù, kí wọ́n sì jó sí i papọ̀ ni a lérò pé ó fà á tí wọn fi níláti dá orin àti ìlù dúró tí wọ́n bá ń sun ìjálá tàbí tí wọ́n ń ṣe àwọn ìṣàré miíràn.

Oríṣiríṣi ni àwọn àpẹerẹ ìṣàré Yorùbá. Ọ̀nà méjì ni àwọn onímọ̀ máa ń sábàá tún wọn pín sí. Ti àkọ́kọ́ ni èyí tí ó gùn lé òdiwọ̀n ìjẹmàgbègbè. Ẹ̀ka méjì ni àtúpínsísọ̀rí eléyìí ní: àwọn tí ó kárí ilẹ̀ Yorùbá àti àwọn tí ó jẹ́ pé agbègbè kan ní pàtó ni a mọ̀ wọ́n mọ́ (Ọlátúnjí 1984). Ọ̀nà kejì ni èyí tí ó lo òdiwọ̀n ìmúlò tàbí ìwúlò. Ẹ̀ka méjì tí a pín ìṣaré Yorùbá sí nipa ìlànà yí ni àwọn ajẹmẹ́sìn àti àwọnaláìjẹmẹ́sìn tàbí tí wọ́n jẹ́ ajẹmáyẹyẹ àríyá (Ògúndèjì 1991, 2000). Ohun tí a ṣe àkíyèsí ni pé púpọ̀ nínú àwọn tí ó jẹ mẹ́sìn yẹn ni wọ́n fẹ́rè jẹ́ tí gbogbòò, tí ó kárí ilẹ̀ Yorùbá. Ohun tí a lérò pé ó fa èyí ni pé gbogbo àwọn òrìṣà pàtàkì pàtàkì tí àwọn Yorùbá ń sìn ni ó pa wọ́n pọ̀, ṣùgbọ́n oríṣiríṣi ni àwọn ọ̀nà ìgbàṣàyẹyẹ àríyá láti agbègbè ẹ̀ka èdè kan dékejì. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àtúnpínsísọ̀rí tí ajẹmọ́-ìmúlò ni a yàn láàyò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí síbẹ̀ a kò ní ṣe aláìmẹ́nu ba ti ìjẹmágbègbè náà nítorí gẹ́gẹ́ bí a ti fi hàn wọn gbẹ́nu lẹ́nu. Ìdí tí a fi yan ti ajẹmọ́mùúlò láàyò ni pé gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú máyàmí ni ọ̀rọ̀ ìmúlò tàbí ìwúlò àti lítíréṣọ̀ alohùn.

Àpẹẹrẹ àwọn ìṣàré Yorùbá ajẹmẹ́sìn tí a óò jíròrò lé lorí nínú kọ́ọ̀sì yí ni ìjálá Ògún, ẹ̀ṣà tàbí iwì egúngún, ìyẹ̀rẹ̀ ifá àti àwọn ọ̀wọ́ tí à mọ̀ sí òrìṣà pípè. Lára ọ̀wọ́ àwọn ìṣàré òrìṣà pípè ni a ti rí Èṣù pípè, Ọya pípè, Ṣàngó pípè àti Ọbàtálá pípè. Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ wí pe gbogbo àwọn wọ̀nyí ni wọ gbìlẹ̀ káàkiri ilẹ̀ Yorùbá, ṣùgbọ́n ìyàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ kò lè má sí, lati agbègbè kan dé èkejì, nípa ṣìgbékalẹ̀ wọn. Àpẹẹrẹ àwọn ti ìṣàré aláìjẹmẹ́sìn tàbí ajẹmáyẹyẹ àríyá ni rárà, ẹkún ìyàwó, yùngbà àti ògbérè tàbí òkú pípè ní agbegbè Ọ̀yọ́,ègè, ìgbálá ní Ẹ̀gbá, olele ní ilẹ̀ Ìjẹ̀ṣà, ọ̀sàrè àti àdàmọ̀ ní Ifẹ̀ pẹ̀lú Ìjẹ̀ṣà, àdàn àti àsíkò ní Òǹdó, rẹ́sọ̀ lághalogho àti ọ̀sẹ́ghẹ̀ ní Ọ̀wọ̀, ẹfẹ̀, àṣamọ̀, alámọ̀ àti ùjamẹ̀ẹ̀sẹ̀ ní Èkìtì.Díẹ̀ ni a óò gbé yẹ̀wò ní kíkún nínú wọn ni iwájú.

### 4.1.3 Orin

Ìwọ̀hùn àti ìwéhùn orin ni ó ṣe wẹ́kú pẹ̀lú ìwọ̀hùn ìlù àti ijó jùlọ nínú àwọn ìsọ̀rí ewì alohùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí à ń gbé yẹ̀wò nínú orí karùn-ún yìí. Ìdí yìí ni a léròpé ó jẹ́ kí Ọlátúnjí (1984) fi orin sí ìparí pátápátá nígbà tí ó ń ṣe àlàyé bí àwọn ìsọ̀rí ewì mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ṣe tò ní ṣísẹ̀ntẹ̀lé ṣàn wọnú ara wọn. Ewì àrángbọ̀ ni ó fi sí ìbẹ̀rẹ̀ ètò ìṣànwọnú ara náà, nígbà tí ó fi ìṣàré sí ààrin gbùngbùn.

Oríṣiríṣi orin ni ó wà káàkiri ilẹ̀ Yorùbá. Bí a bá lo ìlànà ìwúlò wọn, tí ó jẹ ọ̀kan pàtàkì lára fọ́n-ọ́n-rán ọ̀gangan ipò wọn, a lè tún ìsọ̀rí orin Yorùbá pín sí ona mẹ́rin wọ̀nyí: orin ọmọdé, orin ọdún ìbílẹ̀, orin àtìgbàdégbà àti orin àlùjó. A lè tún ṣe àtúnpín orin ọmọdé sí mẹ́ta; orin ìrẹmọlẹ́kún, orin erémọdé àti orin àlọ́ onítàn. Bẹ́ẹ̀ ni orin erémọdé sì tún ṣe é pín sí méjì; ti onídààrayá àti oníjẹ̀lẹ́ńkẹ́. A óò túbọ̀ máa ṣe àlàyé àti àpẹẹrẹ àwọn orín erémọdé wọ̀nyí níwájú. Ṣàṣà ni ọdún ìbílẹ̀ tí kò ní orin kan tàbí èkejì ti à ń kọ sí i ní ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn irú orin ọdún ibílẹ̀ bẹ́ẹ̀ lè tàn kálẹ̀ Yorùbá. Àpẹẹrẹ ni orin ọdún ìbílẹ̀ bí i ti Ọ̀ṣun, Ọbàtálá, Orìṣà oko, Ifá, Ṣàngó àti Ògún. Àwọn mìíràn sì lè jẹ́ ti àdúgbò kan pàtó. Àpẹẹrẹ àwọn èyí ni orin ọdún Òkèèbàdàn ní Ìbàdàn, ọdún Ońmọ̀ká ní Ọ̀fà, ọdún Edì ní Ilé Ifẹ̀ àti ọdún Igogo ní Ọ̀wọ̀ abbl.

### 4.2 Ìtàn ÀrosọỌlọ́rọ̀ Geere

Ọ̀nà mẹ́ta tí ó gbajúmọ̀ jù lọ tí àwọn onímọ̀ máa ń pín ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ geere Yorùbá (àti ti ilẹ̀ Áfíríkà, àti káàkiri àgbáyé) sí ni ìtàn ìwáṣẹ̀, ìtàn akọnikàyéfì àti àlọ́ onítàn. Ìpínsísọ̀rí yìí ni a ó mú lò fún kọ́ọ̀sì wa. Ṣùgbọ́n ẹ jẹ kí á ṣàyẹ̀wò ìpínsísọ̀rí tí Ògúnpòlù dá lábàá ní ṣókí. Ọ̀nà mẹ́rin ni Ògúnpòlù kọ́kọ́ pín àwọn ìtàn àròsọ alohùn sí, ṣùgbọ́n tí ó sọ ọ́ di márùn-ún lẹ́yìnọ̀rẹyìn. Mẹ́rin tàkọ́kọ́ ni fèyíkọ́gbọ́n, orírun, àmúṣagbára àti yẹ́ńwò. Ti àpárá ló fi kún un lẹ́yìnọ̀rẹyìn tí ó fi di márùn-ún. Ìsọ̀rí kéékèké mẹ́ta tí ó tún ti fèyíkọ́gbọ́n sí ni alárọ̀, arúmọlójú àti alálọ̀ọ́. Ti orírun ni ó tún pín sí ìsọ̀rí mẹ́rin mìíràn ti orírún, ìdílé, ìlú,oyè àti ibọ. Ìsọ̀rí kéékè mẹ́rin tí ó pín ti àmúṣagbara sí niakọ̀yà, aṣààbò

awúre àti aṣèwòsàn. Ìsọ̀rí kéékèèké méjì tí ó sì tún ti yẹ̀ńwò sí ni asọṣẹ̀lẹ̀ àti alásọtẹ́lẹ̀. A kò ní àǹfàní láti mọ̀ bóyá àtúnpínsísọ̀rísọ̀rí kéékèkè ìtàn àpárá wà nítorí ìtàn fèyíkọ́gbọ́n nìkan nìkan ni ó tẹpẹlẹ mọ́ nínú iṣẹ́ tí ó ti a mọ̀ tí ó ti mẹ́nu ba ìsọ̀rí tuntun náà. Ó kàn fi àwọn yòókù ṣe àyàbá ni kò tẹnpẹlẹ mọ́ wọn rárá. Àìní àlàyékíkún àti àpẹẹrẹ tí ó péye tó nípa àtúnpínsísọ̀rí Ògúnpòlù ni kò jẹ kí a mú un lò.

### 4.2.1 Ìtàn Ìwáṣẹ̀

Ìtàn ìwáṣẹ̀ ni èdè ìperí tí àwọn onímọ̀ fẹnu kò sí láti fi ṣògbifọ̀ *myth* láti Gẹ̀ẹ́sì sí èdè Yorùbá. Àwọn ìtàn tí ó wà ní ìsọ̀rí yìí ni a fi máa ń ṣàgbékalẹ̀ ìtàn ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀,ìpilẹ̀ṣẹ̀ tàbí ìṣẹ̀dálẹ̀ ilé ayé àti àwọn ẹ̀dá inú rẹ̀. A máa ń fi sọ ìtàn àwọn òrìṣà àti àwọn àkọ́dá ẹ̀dá náà. Ẹnu àwọn àgbàlagbà ni a ti máa ń gbọ́ ọ. A lè bá a pàdé nínú ìtàn ifá, àyájọ àti àwọn lítíréṣọ̀ alohùn àbáláyé Yorùbá mìíràn.

Àpẹẹrẹ ni ìtàn bí Olódùmarè ti rán Ọbàtálá láti wá dá ilé ayé, tí ó sì fún un ni àkùkọ kan, àti erùpẹ̀ tí a bù sínú ìkarahun ìgbín. Ẹ̀wọ̀n ni Ọbàtálá bá rọ̀ láti ọ̀run sí ilé ayé. Omi sì kún ile ayé bámúbámú. Erùpẹ̀ tí ó mú dáni ni ó dà sí orí omi tí àkùkọ sì fi ẹsẹ̀ rẹ̀ tàn án ká orí omi tí ó di ilẹ̀ líle, tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í fẹ̀. Eyí ni ó sì mú kí wọn máa sọ pé ibẹ̀ ni ibi tí ilẹ̀ ti ń fẹ̀ nínú èyí tí orúkọ Ilé Ifẹ̀ ti jẹyọ. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé bí a ti dá ilé ayé nìyí. Ìtàn náà tún fi yé wa pé ọ̀gà ni Olódùmarè rán wá sáyé láti wá ṣe àyẹ̀wò bí ilẹ̀ ayé ṣe le tó. Ìdí nìyí tí ọ̀gà fi ń rọra fi pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ rìn lórí ilẹ̀ náà. Ọbàtálá ni ó léwájú gbogbo àwọn Òrìṣà yòókù rọ̀ wá sílé ayé. Bí ìtàn ìwáṣẹ̀ Yorùbá ti là á yé wa. Òun ni Olódùmarè sì gbé iṣẹ́ ìṣẹ̀dá yòókù lé lọ́wọ́. Ṣùgbọ́n Ọbatálá bá Ògún kẹ́gbẹ́ ẹmu mímu, ó sì mu àmuyó débi pé ó dá ẹ̀dá ọmọ ènìyàn ní ìdákúdàá. Èyí ni ó fà á tí ó fi dá arọ, afọ́jú, odi, asuké abbl. Olódùmarè bínú sí i, ó sì gba iṣẹ́ ìtáyéṣe lọ́wọ́ rẹ̀, ó gbé e fún Odùduwà.

Yàtọ̀ sí Ọbàtálá, Ògún àti Odùdùwà àwọn orìṣà Yorùbá tí ìtàn ìwáṣẹ̀ tún máa ń dá lé ni Ọ̀rúnmìlà, Ṣàngó, Èṣù, Ọya, Ọ̀ṣun, Ọbà abbl. Kò sí àní-àní pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mérìíyìírí wọ́pọ̀ nínú ìtàn ìwáṣẹ̀, síbẹ̀síbẹ̀ àwón Yorùbá gbàgbọ́ pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà ṣẹlẹ̀ rí lójú ayé ní ìgbà tí ojú wà ní orúnkún tàbí ní igbà nàmí-n-nalẹ̀ (Ògúndèjì 2014).

### 4.2.2 Ìtàn Akọnikàyéfì

Ìtàn àkọnikàyéfì ni àwọn onímọ̀ fi ẹnu kò sí láti fi ṣògbufọ̀ *legend* láti Gẹ̀ẹ́sì sí Yorùbá. Ọ̀wọ́ àwọn ìtàn yìí náà ni a mọ̀ sí ìtàn ọjọ́un tàbí ìtà ìgbàanì tẹ́lẹ̀, ṣaájú ìfẹnukò náà. Ó máa ń dá lérí àwọn bába àti ìyá ńlá àti gbogbo ìṣe akọni wọn. Àpẹẹrẹ àwọn baba ńlá àti àwọn ìyá ńlá Yorùbá bí i Olúgbọ́n ti Ilé Igbọ́n, Arẹ̀sà ti Ìrẹsà, Oníkòyí ti Ìkòyí, Fágbàyílà ti Ìlá, Anlùgbùà ti Owu, Ṣódékẹ́ ti Ẹ̀gbá, Mọrèmi ti Ilé Ifẹ̀, Lágelú ti Ìbàdàn

abbl. Ẹnu àwọn àgblagbà náà ni a ti máa ń bá ìtàn akọnikàyéfì. Ó máa ńjẹyọ nínú oríkì orílẹ̀ dáadáa bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kì í ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ rẹ̀. Yíyán ni oríkì orílẹ̀ máa ń yán àwọn ìtàn akọnikàyéfì fẹ́rẹ́. Ìṣẹ̀lẹ̀ mérìíyìírí máa ń wà nínú irúfẹ́ ìtàn yìí náà, ṣùgbọ́n àwọ Yorùbá gbàgbọ́ pé óṣẹlẹ̀ nígbà kan rí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìgbà náà ko jinnà sẹ́yìn tó ti ìtàn ìwáṣẹ̀.

Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ìtàn akọnikàyéfì Mọrèmi fi yé wa pé nígbà tí ogún àwọn imọlẹ̀ kan ń da Ifẹ̀ láàmú léraléra tí wọ́n sì ń kó wọn lẹ́rú, lẹ́rù láìsí ọ̀nà àbáyọ, Mọrèmi tí ó jẹ́ olorì ní àfin Ọ̀ọ̀ni ni ó tánràn ọ̀rọ̀ náà. Ó lọ jẹ́jẹ̀ẹ́ lódọ̀ òrìṣà odò Ẹ̀sìnmìnrìn pé tí òún bá lọ wádìí àwọn imọlẹ̀ náà tí òún lọ ní àlọbọ̀, nǹkan tí Ẹ̀sìnmìnrìn bá fẹ́ gbà ni òún ó fi rúbọ ọpẹ́ sí i. Nígbà tí ogún àwọn irúnmọlẹ̀ náà tún wá kó wọn ní Ilé Ifẹ̀, Mọrèmi jọ̀wọ́ ara rẹ̀ sílẹ̀ tí wọn sì mú un lẹ́rú. Nígbà tí wọn mú un dé Ìlú wọn ni ó tó mọ̀ pé ènìyàn ni wọ́n. Wọ́n kàn ń wọ aṣọ oníko àti ìbòjú ni láti fi máa dẹ̀rù bà wọ́n ní Ilé Ifẹ̀.

Ùgbò ni orukọ àwọn ẹ̀yà náà. Ọba Ùgbò sọ Mọrèmi di ìyàwó rẹ̀, èyí sì túbọ̀ fún Mọrèmi ní ààyè láti rí àṣirí wọn dárdára. Lẹ́yìn tí ó ti mọ àṣirí wọn pé aṣọ oníko wọn kò gbọdọ̀ fojú ba iná, ó sá padà lọ sí Ilé Ifẹ̀, ó sì lọ tú àṣirí náà. Àwọn Ifẹ̀ ti dáná sílẹ̀ ní ìkòríta, ìkòríta, wọ́n sì ti ṣe igi ògùṣọ̀ tí wọn yóò fi ràn án tí àwọn jagunjagun oníko Ùgbò bá tún dé. Nígbà tí wọ́n dé lóòtọ́, àwọn Ìfẹ̀ tan iná ràn wọ́n, wọ́n ṣì ṣẹ́gun wọn. Lẹ́yìn èyí ni Mọrèmi mú ewúrẹ́ akẹ̀ àti ẹ́nlá lọ fi rúbọ ọpẹ́ fú Ẹ̀sìnmìnrìn, ṣùgbọ́n tí kò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà. Ẹ̀sìmìnrìn ní dandanǹdandán Olúorogbo tí ó jẹ́ ọmọ Mọrèmi kan ṣoṣo ni òún ó gbà. Mọrèmi sì níláti fi Olúorogbo rúbọ nítorí ẹ̀jẹ́ tí ó ti jẹ́. Bí Mọrèmi àti ọmọ rẹ̀ Olúorogbo tí a tún mọ̀ sí Ẹ̀là ṣe gba Ilé Ifẹ̀ àti gbogbo Yorùbá sílẹ̀ lọ́wọ́ ogun Ùgbò nìyẹn.

### 4.2.3 Àlọ́ Onítàn

Àwọn Yorùbá kò fi ìgbà kankan gbàgbọ́ wí pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́ onítàn ṣẹlẹ̀ lójú ayé rí. Wọ́n gbà pé àròsọ ni wọ́n. Ìdí sì nìyí ti wọn fi máa ń sọ pé "Irọ́ ní í jẹ́ àlọ́". Bí èyí tilẹ̀ rí bẹ́ẹ̀, òótọ́ ọ̀rọ̀ pọ́ńbélé ni pe wọ́n máa ń lo àwọn àlọ́ náà láti fi kọ́ àwọn ọmọdé. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àgbàlagbà ni ó máa ń sábàá jẹ́ apàlọ́ ní àkókò tí òṣupá ń já tòò lójú ọ̀run lẹ́yìn iṣẹ́ ojúmọ́, àwọn ọmọdé ni ó máa ń jẹ́ olùgbọ́ pàtàkì àlọ́ onítàn. Àlọ́ onítàn náà ni à ń pè ní àlọ́ àpagbè tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ kí àwọn onímọ̀ tó fẹnu kò wí pé àlọ́ onítàn ni kí a máa lò dipò rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí èdè ìperí. Ìdí tí a lérò pé èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé kì í ṣe gbogbo àlọ́ ni ó ni orin tí ó ni bátànì lílé àti gbígbè nínú. Àwọn àlọ́ mìíràn kò tilẹ̀ ní rárárárá.

Ọ̀nà mẹ́ta tí Bámgbóṣe (1969, àtúntẹ̀ jáde 2004) pín àlọ́ onítàn sí ni asọ̀dí-abájọ, akọnilọgbọ́n àti oníjàpá. Ọ̀rọ̀ ìpínsísọ̀rí gan-an kọ́ ni ó jẹ Bámgbóṣé lógún nínú iṣẹ́ rẹ̀, ọ̀rọ̀ àkóónú ni. Òun náà pàápàá ṣe àkíyèsí wí pé ìwọ̀núbọ̀nú wà nínú àwọn ìsọ̀rí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta náà. Nínú ìdánílẹ́kọ̀ọ́ yìí fún ìrọ̀rùn wa ìsọ̀rí méjì gbígbòòrò ni a óò pín àlọ Yorùbá sí ní ìbámu

pẹ̀lú ojú tí àwọn Yorùbá fi máa ń wo àwọn àlọ́ wọn. Àkọ́kọ́ ni ìsọ̀rí àlọ́ olóníjàpá, ìkejì sì ni ìsọ̀rí aláìníjàpá. A tún lè tún ti aláìníjàpá pín sí ìsọ̀rí kekèèké méjì yí: olólórogún àti aláìjólórógun. Àwọn àtúpíntúnpín sísọ̀rí mìíràn lè wà ṣùgbọ́n èyí ni a óò mú lò ní fún ìrọ̀rùn ìkẹ́kọ̀ọ́ wa nínú kọ́ọ̀sì yìí. Ìjàpá ni ó máa ń sábàá jẹ́ olú ẹ̀dá ìtàn nínú àlọ̀ olóníjàpá. Kì í sì í sí ìjàpá nínú ti aláìníjàpá. Ó ṣe é ṣe ṣa kí á rí àwọn ẹ̀dá ìtàn tí ó jẹ́ ẹranko àti àwọn abàmì mìíràn tí ó máa ń wà nínú àlọ́ nínú àlọ́ aláìníjàpá, ṣùgbọ́n kò ní sí ìjápá ní ibẹ̀. Orúkọ mìíràn tí a lè tún pe ìtàn olóníjàpá ni ìtàn ọlọ́lọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́. Ìjàpá sì ni ó máa ń sábàá jẹ́ ẹ̀dá ìtàn ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́ inú àwọn ọ̀wọ́ àlọonítàn náà. Ìjàpá náà ni ẹ̀dá ìtàn ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́ nínú àlọ́ onítàn àwọn Ìgbò ní ìlà oòrùn gúsù Nàìjíríà, ehoro ni irú ẹ̀dá ìtàn yìí nínú àlọ́ onítàn àwọn Hausa ni apá Òkè Ọya, *Ananse* tí àwa mọ̀ sí Aláǹtakùn ni irú ẹ̀dá itàn bẹ́ẹ̀ nínú àlọ́ onítàn àwọn Akan ní Ghana. ìtàn Ìjà orogún ni àwọn ìtàn aláìníjàpá olólórogún máa ń dá lé. Ìyáálé, ìyàwó àti ọkọ wọn ni wọ́n sì máa ń sábàá jẹ́ ẹ̀dá ìtàn pàtàkì inú àwọn ìtàn náà. A óò túbọ̀ máa ṣàlàyé lórí àwọn àlọ́ wọ̀nyí níwájú nítorí pé òun ní ó kàn wá jùlọ nínú ìsọ̀rí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí a ti là kalẹ̀ ní ìhín. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ẹ̀dá ìtàn àtìṣẹ̀lẹ̀ mérìíyìirí wà nínú àwọn ìtàn yókù náà dáadáa síbẹ̀ inú àlọ́ onítàn ni wọ́nn pinminrin sí jù lọ ẹ̀dá. Èyí yóò fara hàn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó ń bọ̀ níwájú.

### 4.3.0 Eré Oníṣe

Ìsọ̀rí kéékèèké méjì tí a óò gbé yẹ̀wò lábẹ́ eré oníṣe alohùn ni eré ọdún ìbílẹ̀ àti eré eégún aláré. Àtúnpín sísọ̀rí ni a óò gbájú mọ́ jù lọ ní ìhín. A óò sọ púpọ̀ nínú ọ̀rọ̀ yòókù dí inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ iwájú.

### 4.3.1 Eré Ọdún Ìbílẹ̀

Ọdún ìbílẹ̀ wà lára àwọn ibi tí a ti lè rí ohun tí a lè pè ní eré oníṣe abáláyé Yorùbá. A ó ṣe àgbéyẹ̀wò bí èyí ṣe jẹ́ bẹ́ẹ̀ dáradára nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ọjọ́ iwájú. Oríṣiríṣi ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá tí ó wà. Àwọn ìgbésẹ̀ inú wọn kì í fi gbogbo ara yàtọ̀ síra. Àkóónú wọn àti ìwúlò wọn tàbí àǹfàní wọn sì wọnú ara púpọ̀pupọ̀. Ẹyọ ọdún ìbílẹ̀ kan kì í ní mọ ní ìwúlò ẹyọ kan ṣoṣo. Gbogbo ìwọ̀nyí ni ó mú kí àtúnpínsísọ̀rí ọdún ìbílẹ̀ ó níra. Oríṣi ìsọ̀rí méjì tí ó gbajúmọ̀ láàrin àwọn Yorùbá ni ọdún ìbílẹ̀ tí ó wà fún ìrántí àti ìkansáárá sí àwọn òrìṣà, babańlá àti àkọni àti èyí tí ó wà fún gbígbé ọba orí oyè lárúgẹ (ọdún ọba). Àpẹẹrẹ ti àkọ́kọ́ ni ọdún Ògún, Ṣàngó, Ọbàtálá, Egúgún, Ọ̀ṣun àti Ọya káàkiri ilẹ̀ Yorùbá. Ọlọ́jọ́ àti Mọrèmi/ Edì ní Ilé Ifẹ̀, Òkèèbàdàn ní Ìbàdàn, Agẹmọ ni Ìjẹ̀bú òde, Ọlọ́sunta ní Ìkẹ́rẹ́ Èkìtì, Ìghogho ní Ọ̀wọ̀, àti Ọ̀ràmfẹ̀ ní Ilé Ifẹ̀. Àpẹẹrẹ ọdún ọba ni ọdún Bẹẹrẹ ni Ọ̀yọ́ ní àtijọ́, ọdún ọba ní Òǹdó àti Ojúde ọba ní Ìjẹ̀bú òde.

### 4.3.2 Eré Eégún Aláré

Eré àwọn eégún aláré wà fún ìdánilarayá. Gbígbé káàkirí láti abúlé dé abúlé àti láti ìlú dé ìlú ni àwọn elé ré náà sì máa ń gbé eré wọn káàkiri. Kò sí ibi tí wọn kò ti lè sẹré. Yàtọ̀ sí eré ṣíṣe tí wọ́n tún máa ń pè ní idán pípa àwọn eléré yìí a tún máa pẹ̀ṣà, wọn a máa kọrin wọn a máa jó sí ìlù bàtá wọn a sì máa tàkìtì. Ògundèji 2000 ṣe àtúnpínsísọ̀rí àwọn eré eégún aláré tí Adédèjì 1969 tọ́ka sí sọ́nà méjì. Ìsọ̀rí àkọ́kọ́ ni ti ajẹmẹ́sìn ìkejì sì ni ti ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tí a tún lè pè ní aláìjẹmẹ́sìn. Ìsọ̀rí kéékèké méjì míràn tí ó tún ti ajẹmẹ́sìn pín sí ni ajẹmórìṣà àti àjẹmẹ́ranko. Ìsọ̀rí kéékèké mẹ́fà tí ó wà lábẹ́ àwọn idán ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni ti ajẹmabirùn, ajẹmájèjì, ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ ọ̀rọ̀ tó ń lọ, ajẹmọ́dàánilẹ́kọ̀ọ́, ajẹmọ́tàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi àti idán àparelé. àwọn ohun tí idán kọ̀ọ̀kan ń fi hàn ni a fi sọ wọ́n lórúkọ yẹn. A óò túbọ̀ máa sàlàyé àti àpeẹ\rẹ nípa wọn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí a ó ṣe ní iwájú.

### 4.4 Ìwọ̀núbọ̀nú

Ìwọ̀núbọ̀nú tí ó wà ní ààrín àwọn ìsọ̀rí ìsọ̀rí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá yìí (àti ti ilẹ̀ Áfíríkà) lápapọ̀ ni ó mú kíàwọn onímọ̀ kan pinnu láti má máa pààlà kankan mọ́ sí ààrín lítíréṣọ̀ alohùn wa tàbí kí wọ́n máa pín wọn sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí.Ohun àkọ́kọ́ tí ó jẹ́ kí ìwọnúbọnú yìí hànde bẹ́ẹ̀ ni pé alohùn ni gbogbo wọn jẹ́. Ohun mìíràn tún ni wí pé láti inú àṣà àti ìrírí kan náà ni gbogbo wọn ti jẹ yọ nítorí náà òye ọ̀rọ̀ kan náà ni máa ń fi hàn. Nígbà tí à ń sọ̀rọ̀ nípa ìṣànwọnú ara àwọn ìsọ̀rí ewì mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ní abala 3.1 a tọ́ka sí i pé nígbà tí Ọlátúnjí ń fi ojú ìwọ́hùn àti ìwéhùn wo ọ̀rọ̀ (ìyẹn ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ ìṣerẹ́ tàbí ìgbékalẹ̀ àwó ewì alohùn náà) àrángbọ́ ni ó sọ pé wà ní igun ìbẹ̀rẹ̀, ìṣàré tẹ̀lé e, orin sì wà ní igun ìparí.

Ṣùgbọ́n bí a bá fi ojú bí àkóónú wọn ṣe ṣàn wọnnú ara wọn wo ọ̀rọ̀ náà àrin gbùngbùn ni àrángbọ́ yóó wà tí àwọn ìṣàré àti orin yóò sì wà ni igun ìbẹ̀rẹ̀ àti ìparí. Ìdí ni wí pé púpọ̀ nínú àwọn àwọn ewì àrángbọ́ máa ń jẹyọ nínú àkóónú àwọn méjì yòókù bí a ti mẹ́nu bà á tẹ́lẹ̀. Oríkì ni ó gbajúmọ̀ jùlọ tí ó sì máa ń jẹyọ nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìṣàré àti orin. Àyọlò ọfọ̀, ẹṣẹ, ifá, òwe, àlọ́ àpamọ̀ àti àrọ̀ náà lè jẹ jáde nínú ìṣàré àti orin. Àwọn ewì tí ó wà ní abẹ́ ìsọ̀rí àrángbọ́ pàápàá a máa tàtarè wọnú àra wọ gẹ́gẹ́ bí Ọlátúnjí (1984) ṣe fi hàn. Bákan náà ni ó jẹ́ wí pé ìṣàré àti orin jọ máá ń wọnú ara wọn ní ìwọ̀núǹbọ̀nú ní àkókò ìṣeré. Nígbà tí Orin ẹlẹ́gbẹ́ ìyàwó ni ó máa ń wọnú ẹkún ìyàwó. Orin ifá ní ó sì máa ń wọnú ìyẹ̀rẹ̀ ifá. Ìjálá àti ẹ̀ṣà egúgún náà sì ni orin ti wọn bákan náà sì ni rárà. À kìí rí orísi ìṣàré mìíràn nigbà tí àwọn apohùn ìṣàré kan bá ń ṣeré àyàfi tí wọ́n bá pe àwọn oníṣàré mìíràn yẹ láti wá bá àwọn tí ó ni ẹ̀yẹ kẹ́yẹ nìkan. Bẹ́ẹ̀ náà sì ni ọ̀rọ̀ rí fún ìsọ̀rí orin kíkọ.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ yìí ni a ti dáwọ́-lé àgbéyẹ̀wò àtúnpíntúnpín sísọ̀rí àwọn ìsọ̀rí ńláńlá mẹ́ta, ewì, ìtàn àròsọ ọlọ́rọ̀ wuuru àti eré oníṣe.

- A tún ewì pín sí ọ̀nà mẹ́ta: àrángbọ́, ìṣàré àti orin.
- Àrángbọ́ ni a tún tún pín sí ọ̀nà méjì: kíkún àti kéékèké.
- Ọ̀nà méjì náà ni a pín ìṣàré sí: ajẹmẹ́sìn àti aláìjẹmẹ́sìn.
- A pín orin sí ọ̀nà mẹ́rin: orin ọmọdé, orin ọdún ìbílẹ̀, orin àtìgbàdégbà àti orin àlùjó. Ọ̀nà méjì tí a tún tún orin ọmọdé pín sí ni ti oníjẹ̀lẹ́ńkẹ́ àti ti onídàárayá.
- Àlọ́ onítàn ni a tún pín sí ọ̀nà méjì: olóníjàpá àti àláìníjàpá. A sì tún ti aláìníjàpá sí olólórogún àti aláìjólórógún.
- Oríṣi eré oníṣe méjì tí a sì mẹ́nu bà ní ti ọdún ìbílẹ̀ àti eégún aláré.
- A kò ṣàì sọ̀rọ̀ nípa ìwọ̀núbọ̀nú tí ó ga tí ó wà láaàrin wọn.

O hàn gbangba pé ìpínsísọ̀rí ewì kún dáadáa. Ìdí ni pé iṣẹ́ tí àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí ewì alohùn Yorùbá pọ̀ ju tí àwọn ìsọ̀rí yòókù lọ dáadáa. Ohun kan tí ó tún hàn gbangba látinú àgbéyẹ̀wò àtúnpínsìsọ̀rí yìí ni pé bí ìyaàtọ̀ ti wà láàrin ìsọ̀rí ìsọ̀rí náà ni gbogbo wọn tún ṣàn wọnú ara wọn tàbí kí a sọ wí pé wọ́n tàtàrè wọnú ara wọn

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ní ṣókí ṣe àtúnpínsísọ̀rí ewì alohùn àrángbọ́.
2. Ìsọ̀rí mélòó ni a lè tún orin Yorùbá pín sí, darúkọ wọn.
3. Jíròrò lóri ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ìtàn ìwáṣẹ̀, ìtàn akọnikàyéfì àti àlọ́ onítàn
4. Dárúkọ àwọn ìsọrí idán tí ó wà nínú ìṣeré eégún aláré.
5. Jíròrò lórí ìwọ̀núbọnú tí ó wà ní ààrín àwón ìsọ̀rí ìsọ̀rí lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Bámgbóṣe, A. 1969 Yorùbá Folktales, *Ìbàdàn*, 6 -12; Àtúntẹ̀jáde nínú Lawal, N. S., Sadiku, N. O. S. àti Dọ̀pámú A. 2000*Understanding Yorùbá Life and Culture*; 547 – 561,New Jersy.

Ògúndéjì, P. A. 1991 *Introduction to Yorùbá Oral Literature*, External studies Programme, Department of Adult Education, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

____________ 2000 *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: A Nigerian Example,* Cultural Studies Group, University of Ìbàdàn,Ìbàdàn.

____________ 2000 Yorùbá Oral Poetry Classification: A Case of Unity in Diversity, *Ìṣẹ̀ṣe: Ìbàdàn Journal of Folklore*. No. 2 o. i. 26 – 36.

____________ 2014 *Yorùbá Drama inTime Perspective, An Inaugural Lecture*, Ìbàdàn University Press, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Ògúnpòlù, B. 1990"Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Lórí Àlọ́ Apagbè," nínú Afọlábí Ọlábímtán (olóòtú) *Aáyan Àwọn Ọ̀mọ̀ràn Lórí Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀*, J. F. Ọdúnjọ Memmorial Lectures,Lagos.

____________ 2000 Ìtàn Fèyíkọ́gbọ́n Yorùbá, nínú Ọmọ́táyọ̀ Olútóyè Ó Pegedé, *Àwọn Àrokọ* -*Akadá fún Yíyònbó Ọ̀jọ̀gbọ́n Adébóyè Babalọlá*. Longman Nigeria Plc., Lagos.

Ọlátúnjí, O. O. 1984 *Features of Yoruba Oral Poetry*, University Press, o.i. 5 – 9,(tí ó dá lórí Ìpínsísọ̀rí),Ìbàdàn.

# MÓDÙ 2 EWÌ ÀLOHÙN

Ìpín 1 Àrángbọ́ Kíkún
Ìpín 2 Àrángbọ́ Kéékèèké
Ìpín 3 Ìṣàré Ajẹmẹ́sìn
Ìpín 4 Ìṣàré Aláìjẹmẹ́sìn
Ìpín 5 Orin

## ÌPÍN 1 ÀRÁNGBỌ́ KÍKÚN

### AKOONU

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròńgbààti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Oríkì
4.1.1 Àsọdorúkọ
4.1.2 Lílo Ọ̀rọ̀ Ìtọ́kasẹ́bí tàbí Ìran
4.1.3 Pípe Ẹni tí à ń kì ní Oríṣiríṣi Orúkọ àti Títọ́ka sí i ní Ọ̀pọ̀lọpọ̀ Ìgbà
4.2 Ẹsẹ Ifá
4.2.1 Ìtàn Sísọ
4.2.2 Ètò/Àbùdá ẸsẹIfá
4.3 Ọfọ̀
4.3.1 Apè
4.3.2 Gbólóhùn Máyẹ̀
4.3.3 Iṣẹ́ tí A Fẹ́ kí Ọfọ̀ Jẹ́
4.3.4 Ìfọ̀rọ̀dárà Alárokò
5.0 Ìsọníṣókí àtiÀgbálọgbábọ̀
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Púpọ̀ tí àkóónú àwọn ewì alohùn àrángbọ́ wọ̀nyí máa ń pọ̀ rẹrẹẹrẹ ni a fi pè é ní àrángbọ́ kíkún láti tọ́ka sí ìyàtọ̀ tó wà lááárín ọ̀wọ́ àrángbọ́ yìí àti àwọn tí àkóónú wọn mọ níba. Ohun mìíràn tí ó tún mú wọn yàtọ̀ sí ọ̀wọ́ kejì tí a sọ pé àkóónú wọn mọ níba (ìyẹn àrángbọ́ kéékèké) ni pé àwọn àgbàlagbà ni ojúlówó aṣàmúlò wọn. Ṣùgbọ́n ṣá o, rántí pé a tọ́ka sí kùdìẹ̀kudiẹ kan tó wà nínú ìpínsọ́wọ̀ọ́ àrángbọ́ yìí pé lótìítọ́ ni àkóónú àrọ̀ máa ń kún ṣùgbọ́n àwọn ọmọdé ni ó ń lò ó. A dábàá pé à bá pín àrọ̀ àti òwe tí òun náà kò kún ojú òṣùwọ̀n pàtàkì méjì tí a fi pín àrángbọ́ sí ìsọ̀rí kíkún àti kéékèké sí ìsọ̀rí alágbedeméjì, ṣùgbọ́n a kò fẹ́ kí ìpínsísọ̀rí àrángbọ́ ju méjì lọ (Wo Módù 1: Ìpín 5 fún àlàyé síwájú sí i).

## 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÀTI AFOJÚSÙN

Nígbà tí o bá ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín yìí tán, wà á ti lè sọ àbúdá mẹ́ta mẹ́ta, ó kéré tán, tí a fi lè ṣe ìdámọ̀ àwọn ewì alohùn àrángbọ̀ kíkún wọ̀nyí: oríkì, ẹsẹ ifá àti ọfọ̀.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Dárúkọ àbùdá àdáni méjì méjì tí ó mọ̀ mọ oríkì, ẹsẹ ifá àti ọfọ̀.
2. Àwọn wo ni ó máa n ṣe àmúlò ẹsẹ ifá àti ọfọ̀, kín sì ni wọ́n máa ń lò wọ́n fún?
3. Kọ àpẹẹrẹ ọfọ̀ kékeré kan sílẹ̀, kí ó sì jẹ́ kí a mọ iṣẹ́ ti a fi jẹ́.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1.0 Oríkì

Oríkì ni ewì alohùn Yorùbá tí a maá ń fi ṣe àpọ́nlé ènìyàn. A tún le sọ pé àwọn àkójọpọ̀ orúkọ̀ àti ìpèdè àpọ́nlé ni oríkì, èyí tí a fi ń ṣàpèjúwe ẹni(tàbí nǹkan) tí ó ni àwọn orúkọ àpọ́nlé náà, láti fi ìrísì, ìṣesí àti ìhùwàsí olúwa rẹ̀ hàn. Oríkì le jẹ́ àdáni tàbí àjùmọ̀ni. Oríkì àdáni ni àwọn oríkì tó jẹ́ pé ènìyàn kan ṣoṣo ló ni ín. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ oríkì orúkọ, oríkì àlàjẹ́/ìnàgijẹ àti oríkì bọ̀rọ̀kìnní. Oríkì orúkọ ni "ẹyọoríkì kan" (Babalọlá, 1975:4) tàbí oríkì ṣókí tí a máa ń fí pe ènìyàn gẹ́gẹ́ bí a ṣe ń fi orúkọ àbísọ pè é. Bí ọkùnrin ṣe ní oríkì orúkọ ni àwọn obìnrin náà ní. Àjàní, Àkànní, Àlàbí, Ìṣọ̀lá, Àlàmú, Àkànmú àti Àlàó jẹ́ àpẹẹrẹ oríkì orúkọ ọkùnrin. Àbẹ̀ní, Àṣàbí, Àjíkẹ́, Àlàkẹ́, Àdùkẹ́ àti Àjíhún jẹ́ àpẹẹrẹ oríkì orúkọ obìnrin. Oríkì àlàjẹ́ lè gùn ju oríkì orúkọ lọ ní tirẹ̀, ṣùgbọ́n níwọ̀nba náà ni. Àpẹẹrẹ àlàjẹ́ ni Eyínfúnjowó, Ọ̀pẹ́lẹ́ńgẹ́, Àdúmáadán, Ìbàdíárán, Atẹ́rẹrẹpàdéòwè, Akójẹńbú, Adọgbadélẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (wo Babalọlá, 1975: 4–5 fún àpẹẹrẹ sí i). Oríkì àdání ni oríkì bọ̀rọ̀kìnní náà, àwọn àbùdá ìrísí, ìṣesí àti ìhùwàsí bọ̀rọ̀kìnní tí à ń kì ni ó máa ń kórajọ di oríkì bọ̀rọ̀kìnní. Oríkì orúkọ àti oríkì àlàjẹ́/ìnagijẹ ẹni tí à ń kì náà máa ń jẹ́yọ nínú oríkì bọ̀rọ̀kìnní.

Oríkì àjùmọ̀ni ni àwọn oríkì tó jẹ́ pé àwọn ènìyàn tó jìjọ ni ín pọ̀. Àpẹẹrẹ irúàwọn oríkì yìí ni oríkì orílẹ̀, oríkì ìdílé àti oríkì ìlú. Àpẹẹrẹ oríkì orílẹ̀ ni oríkì Oníkòyí, Arẹ̀sà, Olúgbọ́n, Olúòjé, Òpómúléró, Olúfẹ̀, Ìrèmògún, Olókùnẹṣin, Ajíbógundé, Ìlọ̀kọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (wo Babalọla, 2001 fún àpẹẹrẹ oríṣìíríṣìí oríkì orílẹ̀ Yorùbá). Kò sí ìlú tí kò ní oríkì ní ilẹ̀ Yorùbá, bẹ́ẹ̀ sì ni àwọn ìdílé kọ̀ọ̀kan tí ó wà nínú ìlú a tún máa dá ní oríkì. Yàtọ̀ sí gbogbo ìwọ̀nyí, ó fẹ́rẹ̀ má sí ohun tí Yorùbá kò ní oríkì fún. Bí àpẹẹrẹ wọ́n ní oríkì fún ikú, ewéko, oríṣìíríṣìí ẹrànko, omi, òkè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. "Oríkì ẹtu" tó jẹ́ ẹranko igbó jẹyọ nínú Yemitan (1963 tí a tún tẹ̀ ní 1973:56). Àwọn àbùdá pàtàkì tí a lè fi ṣèdámọ̀ oríkì tí á óò sì

jíròrò lé lórí ni àsọdorukọ, àwọn ọ̀rọ̀ ìtọ́ka sẹ́bi tàbí ìran, pípe ẹni tí à ń kì ní oríṣìíríṣìí orúkọ àtí títọ́ka sí i ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà.

### 4.1.1 Àsọdorúkọ

Yorùbá gbà pé, orúkọ ọmọ ni ìjánu ọmọ. Wọn a sì tún máa sọ pé orúkọ ń roni, oríkì a sì máa ròòyàn. Nítorí náà àwọn Yorùbá kì í kù gìrì sọmọ ní orúkọ. Wọ́n máa ń kíyèsí ìrísí, ìṣesí àti àwọn ìṣẹlẹ̀ tí ó rọ̀gbà yí bí wọ́n ti bí ọmọ ká, kí wọ́n tó sọ ọ ní orúkọ. Oríṣìíríṣìí ni orúkọ tí Yorùbá máa ń sọmọ. A lè pin wọn sí ọ̀nà mẹ́rin yìí: orúkọ àmútọ̀runwá, àbísọ àlàjẹ́/ìnagijẹ àti tí àbíkú. Orúkọ àmútọ̀runwá ni àwọn orúkọ tí ó ń ṣàfihàn bí ati bí ọmọ náà sáyé láti inú ìyá rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ọmọkùnrin tí a bí tí ó gbé ibi rẹ̀ kọ́rùn ni Ọ̀jó, bí ó bá jẹ́ òbìnrin, Àìná ni Yorùbá ń pè é. Bí a bá bí ọmọ ṣùgbọ́n tó jẹ́ pé ẹsẹ̀ ni ọmọ náà kọ́kọ́ yọ jáde lásìkò tí ìyá rẹ̀ ń rọbí, Ìgè ni à ń pe irú ọmọ bẹ́ẹ̀.

Bí ọmọ bá wà nínú àpò nígbà tí a bí i, Ọ̀kẹ́ ni orúkọ àmútọ̀runwá ọmọ yìí. Àkọ́kọ́ nínú àwọn ọmọ tí a bí ní méjì papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà (ìbejì) ni Táyéwò, èyí tí ó sì wáyé ṣìkejì ni Kẹ́yìndé. Ìdòwú ni ọmọ tí a bí tẹ̀lé àwọn ìbejì, Àlàbá sì ni à máa ń pe ọmọ tí á bá bí tẹ̀lé Ìdòwú. Orúkọ àbísọ ni orúkọ tí a sọ ọmọ nígbà tí a bí i. Òhun ni a lè pè ní orúkọ àkọ́kọ́ fún ọmọ. Àpẹẹrẹ orúkọ àbísọ ni orúkọ ìdílé bí Àyànwálé (fún àwọn ìdílé onílù), Adéwọlé (àwọn ìdílé ọba), Ọdẹníyì (fún àwọn ìdílé ọlọ́dẹ) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lára orúkọ Yorùbá ni oríkì àbísọ tí a mẹ́nu bà lókè náà wà. Bí orúkọ àbísọ ni òun náà ti rí. Orúkọ ìnagijẹ, àpèjẹ́ tàbí àlàjẹ́ ní tirẹ̀ máa ń jẹ́ èyí tí a fúnni nígbà tí olúwarẹ̀ ń dàgbà, tàbí tí ó tilẹ̀ ti dàgbà tán. Àwọn ìyàwó ilé, ẹlẹgbẹ́ ẹni àti àwọn apohùn níí máa fúnni ní orúkọ ìnagijẹ. Àpẹẹrẹ ni Ọ̀pẹ́lẹ́ńgẹ́, Ṣékérewéle, Agùntáṣọolò àti Alásè. Irú orúkọ mìíràn tí àwọn Yorùbá tún máa ń jẹ́ ni orúkọ àbíkú. Àbíkú ọmọ ni ọmọ tí ó kú ní rèwerèwe. Yorùbá gbàgbọ́ pé irú ọmọ bẹ́ẹ̀ a tún máa padà wá, tí àwọn òbí rẹ̀ yóò tún un bí, ṣugbọ́n bí óti ń wá náà ni yóò tún máa lọ láìpé ọjọ́. Ìpọ́njú nláǹlà ni èyí máa ń jẹ́ fún àwọn obí abíkú ọmọ bẹ́ẹ̀. Nígbà tí ó bá kọ́kọ́padà wá wọ́n lè máa fún ní orúkọ abíkú tí wọ́n fi ń pàrọwà fún un bí i Dúrójayé, Dúróoríkẹ̀ẹ́, Málọmọ́, Mákú abbl. Lẹ́yìn ìgbà tí ọ̀rọ̀ rẹ̀ bá sú wọn, wọ́n á wà bẹ̀rẹ̀ sí i fún un ní orúkọ ìṣáátá bí i Ajá,Ọmọṣáá, Kòsọ́kọ́, Ìgbẹ́kọ̀yí abbl.

Orúkọ tí a ṣẹ̀dá ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn orúkọ Yorùbá, ìbáà jẹ́ ti àbísọ, àmútọ̀runwá, àlàjẹ́/àpèjẹ́/ ìnagijẹ tàbí àbíkú, wọn a sì máa jẹyọ nínú oríkì. Orúkọ ìṣẹ̀dá yìí jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì tí a ń lò láti dá oríkì mọ̀. Ìlànà ìṣẹ̀dá orúkọ náà ni a tún mọ̀ sí ìsọdorúkọ. A lè sọ gbolóhùn kan tàbí àpólà gbólóhùn di orúkọ nípa lílo wúrẹ̀n àsọdorúkọ. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ bí àsọdorúkọ ṣe jẹyọ nínú àyọlò oríkì bọ̀rọ̀kìnní ìsàlẹ̀ yìí:

Ẹgbẹ́róungbé, Oyèwọlé, Fófó-l'áwọ̀.

Ọkúnrin wọ̀ǹkúkú-wọ̀ǹkọ̀kọ̀.
A-kí-Ṣọ̀npọ̀nná-máà-kí-ẹni-tí-ó-mú.
A-bi-akọ-ṣọ̀npọ̀nná-kàkà-l'aiyà.
Ó ṣe àná oògún bí ẹni ṣ'àná ìyàwó.
Ìdí kò gbà oògùn, ó kó ìyókù há pàrá.
Ò-f'ọmọrí-odó-kì-oògùn-s'ọ́fun.
Ò-d'órita-mẹ́ta-yà-sí-mẹ́tẹ̀ẹ̀ta.
Ó yí Onígbàgbọ́ tì bí ẹni yí'dó.
Ó fi kùmọ̀ bá omi bà Ìmàle.
Ẹgbẹ́róungbé, Oyewọlé, Ọ̀kánjúà-l'óyè.
Ọmọ A-ró-hánrán-má-gbẹ.
Àrẹ Af'àrà-k'ọ́mọ-àdúgbò.
Ọmọ Ọ̀bàbà-tí-íbà-ará-ẹ̀-lẹ́rù.
Alúkútú ọmọ ajá.
Ò-dé-'bi-ìjà-wú-bàǹtùbantu. (Babalọlá, 1975:103)

Oríkì Baálẹ̀ Oyèwọlé Wọ̀ǹkúkú ni oríkì yìí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ orúkọ tí a fi júwe Baálẹ̀ náà nínú oríkì yìí ló jẹ́ orúkọ tí a ṣẹ̀dá. Èyí túmọ sí pé a sọ wọ́n di orúkọ, yálà nípa lílo wúrẹ̀n àsọdorúkọ bí a ti ṣàlàyé tàbí ìlànà ìsọdorúkọ mìíràn. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, àpólà ìṣe ni "... kí Ṣọ̀npọ̀nná máà kí ẹni tí ó mú", "... bi akọ ṣọ̀npọ̀nná kàkà l'aiyà," "... f'ọmọrí odó ki oògùn s'ọ́fun" "... dé oríta mẹ́ta yà sí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta," "... ró hánrán má gbẹ," àti "... dé ibi ìjà wú bàǹtùbantu." A sọ àwọn àpólà ìṣe yìí di orúkọ ni nípa lílo wúrẹ̀n àsọdorúkọ /a-/ àti /o-/ àti /ò-/ tí a tún mọ̀ sí àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ mọ́ àpólà ìṣe náà gẹ́gẹ́ bí ó ti tọ́.

Ó yẹ kí a kíyèsí i pé ìgékurú Amọ́-fófó-l'áwọ̀ (A + mọ́+ fófó + ní + àwọ̀) ni "Fófó-l'áwọ̀"tí pe Baálẹ̀ náà. Ó yẹ ká tọ́ka sí i pé orúkọ àbísọ ni Ẹgbẹ́róungbé (Ẹgbẹ́ + rí óhun + gbé), Oyèwọlé (Oyè+ (wọ inú) + ilé). Ní àfikún, kì í ṣe ìlànà ìsọdorúkọ aláfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ ni a lò láti ṣẹ̀dá àwọn orúkọ àbísọ méjèèjì tí aṣẹ̀ṣẹ̀dárúkọ tán àti àwọn àlàjẹ́ méjì yìí: Ọ̀kánjúà-l'óyè (Ọ̀kánjúà-ní-oyè) àti Ọ̀bàbà-tí-íbà-ará-ẹ̀-lẹ́rù (Ọ̀bàbà + tí + í + ba + ara + rẹ̀ ní + ẹ̀rù) tí a fi pe Báàlẹ̀ náà. Ìsúnkì àpólà orúkọ ni wọ́n jẹ́ gẹ́gẹ́ bí a ti tọ́ka sí i nínú àwọn àkámọ́ yẹn.Àpẹẹrẹ àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ àsọdorúkọ /oní-/ yọ nínú oríkì bọ̀rọ̀kìnní ti Ààrẹ Látòóṣà ti Ìlú Ìbadàn.

Onígọ̀ǹbọ́-wúrà, ọkọ Ọ̀ṣunbùnmi.
Gbọn-gbọn bí ọkọ́.
Àdá-f'ìrù ṣọkùnrin.
Ìran gangan-jígan.
Ará gbogbo kìkì oògùn wonkoko (Babalọlá, 1975: 90)

Nínú oríkì òkè yìí, àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ àsọdorúkọ "oní-" ni a sọ mọ́ àpólà ọ̀rọ̀ orúkọ "gọ̀ǹbọ́ wúrà" láti fún wa ní orúkọ tuntun "Onígọ̀ǹbọ́-wúrà".

Gbogbo àwọn ọ̀nà tí à ń gbà ṣẹ̀dá orúkọ nínú èdè Yorùbá ni a lè bá pàdé nínú oríkì. Nígbà mìíràn, a le ṣe àpètúnpé fún àpólà ìṣe láti ṣe ìsọdorúkọ. Ìwúlò àsọdorúkọ nínú oríkì ni láti le ṣe àpèjúwe àbùdá ẹni tí à kì ní ṣokí láì fọ̀rọ̀ ṣòfò. Èyí a máa fi àyè sílẹ̀ fún ẹni tí ó ń kini lati fi ọ̀rọ̀ ya àwòrán ẹni tí ó ń kì sí olùgbọ́ rẹ̀ ní ọ̀kàn.

### 4.1.2 Lílo Ọ̀rọ̀ Ìtọ́kasẹ́bí tàbí Ìran

Èyí ni kí á lo ọ̀rọ̀ tí ó le tọ́ka sí ẹbí tàbí ìran ẹni tí à ń kì. Àwọn ọ̀rọ̀ ìtọ́kasẹ́bí tàbí ìran wọ̀nyí máa ń fi ìbátan ẹni tí à ń kì hàn. Àpẹẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀ ìtọ́kasẹ́bì tàbí ìtọ́kasíran tí ó wọ́pọ̀ jùlọ nínú oríkì Yorùbá ni baba, ọkọ, ọmọ àti aya. Èyí a máa jẹ́yọ nínú àwọn férémù àpólà orúkọ yìí; "Ọmọ...", "Baba...", "Ọkọ..." àti "Aya...". Ìlò "Aya..." kò wọ́ pọ̀ nínú àwọn oríkì orílẹ̀àbáláyé Yorùbá nítorí pé Yorùbá kì í tọ pinpin ìran wọn sí ìdí obìnrin láti ìpìlẹ̀ wá náà, ṣùgbọ́n èyí ti ń yi padà lóde òní.Ṣé àṣà kì í dúró rigidi sí ojú kan; bí ayé ṣe ń yí náà ni àṣà náà ń yí. Nígbà tí a bá ń ki òbìnrin tó jẹ́ gbajúmọ̀ láwùjọ òde òní ni a máa ń lo "Aya ...." Ẹ jẹ́ kí á wo bí àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀ ìtọ́kasẹ́bí ṣe jẹyọ nínú àpẹẹrẹ oríkì bọ̀rọ̀kìnní méjì ìsàlẹ̀ yìí:

1. Bísíolú ò! T'ọba l'àṣẹ

Morákingbéjó Ọba, Sáákì!<br>
Olúwòó<br>
Morákinyọ̀ t'ó l'àṣẹ.<br>
Ajíbádé Ọba ọmọ Lámúye.<br>
Ìgbín, "kaa!"<br>
Ẹ̀bìtì, "kaa!"<br>
Ẹ̀bìtì tí kò gbójú,<br>
Wọn ò le pa ìgbín, ọkọ Farayọ́lá (Babalọlá, 1975: 53)

2. Àkàndé ọkọ Morẹ́nikẹ́.

Taa l'ó gbọ́dọ̀ gbàgbé?<br>
Oníjágbójù, ijọ́ ọ̀sán fẹ́ íd'òru.<br>
Igbó fi dúdú ṣ'ọlá, ọkọ Adédoyìn, Mágọ̀bọn, ọkọ ìyá Bádárù. (Babalọlá, 1975: 49)

Oríkì 1òkè yí jẹ́ ti Adúbíàrán Sèédù. Nínú oríkì yìí ni a ti tọ́ka sí bọ̀rọ̀kìnní náà gẹ́gẹ́ bí ọba, a pè é ní "ọmọ Lámúye". Bákan náà, a tún tọ́ka ìbátan rẹ̀ mìíràn nígbà tí ó pè é ní ọkọ Farayọ́lá. Oríkì Olúwo Àbá-nikán-ńdá Àmídà ni oríkì 2 òkè yẹn. A pe Àbá-nikán-ńdá Àmídà ní "Àkàndé ọkọ Morẹ́nikẹ́" nínú àyọlò náà. Bákan náà ni a pè é ní ọkọ Adédoyìn àti ọkọ ìyá Bádárù. Pípe ènìyàn ní ọmọ lágbájá tàbí ọkọ tẹ̀mẹ̀dù fi ìbatan ẹni tí a kì náà hàn ni. Ìwúlò lílo orúkọ ìtọ́kasẹ́bí ni láti ṣe jẹ́ kí á dá ẹni tí à ń kì náà mọ̀ yàtọ̀ ketkete sí ẹlòmìíràn, tí wọ́n lè jọ

máa jẹ́ orúkọ kan náà. Yàtọ̀ sí èyí, ohun ìyangàn ni fífi baba, ìyá, ìyàwó, ọ̀rẹ́ tàbí àwọn ìbátan ẹni tó wojúùrí kini.

Ohun kan tí ó yẹ kí a tọ́ka sí ni wí pé, ìlò "ọmọ ..." kò ní ìtumọ̀ ajẹmọ́ ìbí/ tàbí ìtọ́ka sẹ́bí ní gbogbo ìgbà. Níbààmu pẹ̀lú èrò Ọlátúnjí (1984), àwọn apohùn àtijọ́ a máa lò ó gẹ́gẹ́ bí i àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ láti tọ́ka sí àjọṣepọ̀ mìíràn kan tàbí èkejì tó wà ní àárín ẹni tàbí orílẹ̀ tí à ń kì àti àwọn ohun àyíká rẹ̀. Nígbà tí a bá ki orílẹ̀ Òpómúléró wí pé,

Ọmọ kúlúkúlu aṣọ
Ọmọ òdù òdù aṣọ
Ọmọ òdù òdù ìlẹ̀kẹ̀
Ọmọ òdù ìlẹ̀kẹ̀ kò rínú kọ́rọ̀ mí-ìn sí
Ọmọ rírí tí í máṣọ ọ́ wọmi
Kẹ̀kẹ́ ta dídùn
Aṣọ lèdìdì ènìyàn

Ó dájú pé àjọṣe ti ìbí kọ́ ni "Ọmọ ..." ń tọ́ka sínínú àwọn ìlà àyọlò òkè yẹn. Àjọṣe tí àwọn ìran Òpómúléró ní pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ tí órọ̀ mọ́ ohun ọ̀ṣọ́ ara (aṣọ àti ìlẹ̀kẹ̀) nítorí pé ọmọ ìran iléọla ni wọ́n láti ààrọ̀ ọjọ́, àti pààpàá jù lọ nípasẹ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀ òwú àti aṣọ híhun tí a mọ àwọn babańlá wọn mọ́. Èyí ni a lérò pé wọ́n ń tọ́ka sí nípasẹ̀ ìṣàmúlò "Ọmọ..." àti àwọn ìpèdè yòókù lápapọ̀; kì í ṣe pé aṣọ àti ìlẹ̀kẹ̀ ni ó bí wọ́n lọ́mọ. Síwájú sí i wọn a tún máa kì wọ́n ní:

Ọmọ fúrúńtákí  N ó relé wa
Ma lọ̀ọ́ jẹ̀gbẹ iṣu lÁmúkúderin
Àjẹfẹ̀yìntì niṣu ègbodò (Babalọla 2001: 24)
Bí a ti ń a wọ́n pọ̀
Wọn ò téṣú
Ọmọ eṣú yaálé
Ọmọ eṣú yaóko (Babalọla 2001: 28)

Ìtọ́ka sí wí pé àwọn baba ńlá ìran yìí tún jẹ́ àgbẹ̀ oníṣu ni "Ọmọ fúrúńtáki"(oríṣi ẹgbẹ iṣu kan) ń fi hàn nínú àyọlò àkọ́kọ́. "Ọmọ eṣú yaálé, Ọmọ eṣú yaóko" inú àyọlò látinú oríkì Òpómúléró kan náà oríkì kejì ń tọ́ka sí ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn akọni-kàyéfì kan tí ó sọ nipa bí kòkòrò eṣú ṣe jẹ oko òwú àwọn babańlà ìran yìí ni. Ohun tí wọn ń sọ kì í ṣe pé eṣú àti iṣu ni ó bí ìran náà, bí kò ṣe pé wọ́n wá láti ìran tí wọ́n ní ìrírí tí a ti tọ́ka sí.

### 4.1.3 Pípe Ẹni tí à ń Kì ní Oríṣiríṣi Orúkọ àti Títọ́ka sí i ní Ọ̀pọ̀lọpọ̀ Ìgbà

Bí a bá wo àpẹẹrẹ méjèèjì tí a kọ́kọ́ mú wá ní 3.1.2, ṣaájú ti Òpómúléró a ó rí i pé a pe ẹnìkan ṣoṣo ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ orúkọ. Adúbíàrán Sèédù ni a pè ní

Bísíolú, Morákingbéjó, a pè é ní Ọba, òun yìí kan náà ni Olúwòó, a tún pè é ni Morákinyọ̀. Akéwì tún tọ́ka sí Sèédù gẹ́gẹ́ bí Ajíbádé. Bákan náà nínú àyọlò kejì, Olúwo Àbá-nikán-ńdá Àmídà ni a tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí Àkàndé, òun náà tún ni Oníjágbójù, tí a sì tún tọ́ka rẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi Mágọ̀bọn. Gbogbo ìwọ̀nyí jẹ́ títọ́ka sí ènìyàn kan ṣoṣo ní àimọye ọ̀nà tàbí pípe ènìyàn kan ṣoṣo ní oríṣìíríṣìí orúkọ.

## 4.2 Ẹsẹ Ifá

Ewì yẹ̀ńwò ni ẹsẹ ifá jẹ́. Ó jẹ́ àpilẹ̀ṣọ àlàyé tí àwọn babaláwo máa ń fi ń tú ifá tí ó bá jẹ jáde nígbà tí wọ́n bá ń ṣe àyẹ̀wò ifá. Yorùbá gbà pé ifá ni ọ̀nà àyẹ̀wò tí ó pegede jùlọ. Àwọn babaláwo tí wọ́n jẹ́ ẹlẹ́sìn Ọ̀rúnmìlà ni ó máa ń dá ifá. Kì í ṣe gbogbo ẹlẹ́sìn Ọ̀rúnmìlà yìí ní ó mọ ifá dá, àwọn tí ó bá kọ́ ẹ̀kọ́ dídá ọwọ́, ètìtẹ̀ alẹ̀ àti ẹbọ kíkà nìkan ni ó máa ń mọ ifá dá dójú àmì. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé dídá ọwọ́, ètìtẹ̀ alẹ̀ àti ìkara ẹbọ ni òṣùwọ̀n pàtàkì láti mọ babaláwo tó gbọ́fá yanranyanran. Ọdún díẹ̀ kọ́ ni wọ́n fi ń kọ́ ifá, bí àwọn ọmọ ẹ̀kọ́ṣẹ́ ifá bá tí ń kọ́ bí wọn yóó ṣe máa lo yàlá ọ̀pẹ̀lẹ̀ (okùn tí a fi èso ọ̀pẹ̀lẹ̀ sín) tàbí èkùrọ̀ ifá (ikin) dáfá ni wọn yóò máa kọ́ bí wọn yóò ṣe máa ki àwọn ẹsẹ inú odù ifá àti bí wọn yóò ṣe máa ṣe àlàyé tó wà ní ìdí ẹsẹ ifá odù ifá kọ̀ọ̀kan tí ó bá ń jẹyọ tí wọ́ sì kì. Ojú odù ni orí (ìsọ̀rí àwọn ẹsẹ)tí ó wà ní inú ifá. Mẹ́rìndínlógún ni àwọn orí orí inú ifá, tí ó jẹ́ ojú odù jẹ́. Àwọn ojú odù mẹ́rìndínlógún wọ̀nyí ni Èjì ogbè, Ọ̀yẹ̀kú méjì, Ìwòrì méjì, Òdí méjì, Ìròsùn méjì, Ọ̀wọ́nrín méjì, Ọ̀bàrà méjì, Ọ̀kànràn méjì, Ògúndá méjì, Ọ̀sá méjì, Ìká méjì, Òtúrúpọ̀n méjì, Òtúá méjì, Ìrẹtẹ̀ méjì, Ọ̀sẹ́ méjì àti Ọ̀fún méjì. Nígbà tí ojú odù jẹ́ mẹ́rìndínlógún (16), àwọn ojú odù kọ̀ọ̀kan wọ̀nyí náà tún pín sí ọmọ odù mẹ́rìndínlógún-mẹ́rìndínlógún. Bí a bá ṣe àròpọ̀ àwọn ọmọ odú wọ̀nyí pẹ̀lú àwọn ojú odù ifá, gbogbo odù ifá tí a ní jẹ́ ọ̀tàlérúgba-dín-mẹ́rin (256). Bí a bá yọ ojú odùn mẹ́rìndínlógún kúrò nínú ọ̀tàlérúgba-dín-mẹ́rin, a jẹ́ pé tí a ní jẹ́ òjìlérugba (240).

Bí a ṣe máa ń ní àwọn ọmọ odù yìí ni ṣíṣe àmúlù tàbí àdàpọ̀ odù méjì. Bí a bá ṣe àdàpọ̀ odù méjì, àpẹẹrẹ àwọn àmúlù tàbíọmọ odù Ogbè díẹ̀ nìyí: Ogbèyẹ̀kú, Ogbèdí, Ọ̀bàràǹbogbè, Ọ̀wọ́nrísẹ̀, Ogbèsá, Òtúrúpọngbè abbl.

Odù ifá kọ̀ọ̀kan ni ó ní oríṣiríṣi ẹsẹ ifá nínú. Èyí já sí pé oríṣiríṣi ẹsẹ ifá ni ó wà nínú odù kan ṣoṣo. Gẹ́gẹ́ bí erùpẹ̀ ilẹ̀ ṣe pọ̀ bẹ́ẹ̀ ni àwọn ẹsẹ ifá ṣe pọ̀. Ibú ìmọ̀ tí babaláwo kan ṣoṣo kò le wẹ̀ tán ni. Bí babaláwo kan bá ki ẹsẹ ifá kan bákan, ọ̀tọ̀ ni bí babaláwo mìíràn yóó ṣe máa kì í, ìdí ni pé àkójọ gbogbo ọgbọ́n ayé tí ẹnìkan ṣoṣo kò le mọ̀ tán ni ifá. Bí àwọn babaláwo bá dá ifá, tí ifá kan sì jẹyọ, àwọn babaláwo a máa ránńṣẹ́ sí àwọn babláwo mìíràn bí ó bá jẹ́ pé bí wọ́n ṣe ń ki ifá tí ó jáde náà kò bá tí ì jánà. Àwọn babaláwo gbà pé ifá kì í parọ́, torí náà, wọn yóò máa ṣe àwárí àwọn awo tó le ki ifá tó jadé náà ní oríṣìíríṣìí títí yóò fi bá ohun tí wọ́n torí ẹ̀ dá ifá mu.

Yorùbá ní ìgbàgbọ́ nípa àkúnlẹ̀yàn àti ìpín. Gẹ́gẹ́ bí ìtàn àtẹnudẹ́nu Yorùbá kan ṣe fi hàn, nígbà tí gbogbo ènìyàn ń yan ìpín, Irúnmọlẹ̀ kan ṣoṣo tí ó ṣojú ni Ọ̀rúnmìlà. Ìdí nìyí tí wọ́n fi ń pè é ní Ẹlẹ́rìí-Ìpín. Torí pé ìpín yíyàn ṣojú Ifá tí a tún mọ̀ sí Ọ̀rúnmìlà, ni ó ṣe nímọ̀ nípa àyànmọ́, tí àwọn Yorùbá sì máa ń sá tọ̀ ọ́ fún ìrànlọ́wọ́ láti ṣe àyẹ̀wò nípa ìpín wọn. Nígbà tí Ọ̀rúnmìlà ń kúrò ní òde àyé, ó sì fi ikin (èkúrọ́ ifá) rọ́pò ara rẹ̀, pé bí àwọn ènìyàn bá ti fẹ́ mọ̀ nípa ìpín wọn, ikin tí òun fi sílẹ̀ ni kí wọ́n máa bi. Ó ní bí wọ́n bá fẹ́ owó, òun ni kí wọ́n máa bi, bí wọ́n bá fẹ́ ilé, ikin ni kí wọ́n máa bi, bí wọ́n bá fẹ́ ọmọ, ikin ni kí wọ́n máa bi, bí wọ́n bá ń fẹ́ ire gbogbo, ikin náà ni kí wọ́n máa bi. Àwọn ìṣòro tó ṣẹlẹ̀ ní ìgbà ìwáṣẹ̀ àti ọ̀nà àbáyọ sí àwọn ìṣòro wọ̀nyí ni ó kórajọ sínú ẹsẹ ifá. Torí pé ìṣẹ̀lẹ̀ ìgbà ìwáṣẹ̀ ni àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ẹsẹ ifá, ìdí nìyí tí ìtàn sísọ fi jẹ́ àbúdá ẹsẹ ifá kan pàtàkì.

## 4.2.1 Ìtàn Sísọ

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní, "Bọ́mọ ò bá bá ìtàn, yóò bá àrọ́bá, àrọ́bá sì ni baba ìtàn". Ọ̀rọ̀ ẹsẹ ifá kọjá ìtàn lásán. Ìdí ni pé ìtàn ìtáyéṣe ni. Bí ó ti wà fún ìwòsàn, ni ó wà fún yíyanjú oníruurú ìṣoro ẹ̀dá. Yorùbá gbà pé kò sí ohun tí ó le ṣẹlẹ̀ sí ẹ̀dá alààyè kan ní orílẹ̀ ayé yìí tí kò ti ṣẹlẹ̀ sí àwọn ẹ̀dá ìgbà ìwáṣẹ̀ tàbí ti ìgbàànì, tó ti gbé yálà ìsálú ọ̀run tàbí ìsalú ayé mìíràn tó yàtọ̀ sí tiwa, tàbí ayé tiwa yìí náà.

Ìdí nìyí tí wọn fi máa ń sọ pé "Kò sí ohun tuntun lábẹ́ ọ̀run" àti wí pé "A kò rírú eléyìí rí, ẹ̀rù ni a fi ń dá ba ọlọ́rọ̀". Nígbà ìwáṣẹ̀, ifá ni ọ̀nà pàtàkì tí àwọn ènìyàn ń lò fún ìtọ́nisọ́nà. Níwọ̀n ìgbà tí àwọn Yorùbá gbà pé kò sí ohun tí ifá kò fá tán, kò sí ìṣoro náà bí ó ti wù kí ó le tó, tàbí kí ọ̀rọ̀ rújú tó ti ifá kò ní í yanjú rẹ̀. Gbogbo àwọn ìtàn tó rọ̀ mọ́ ẹsẹ ifá wọ̀nyí ni àwọn babaláwo mọ̀. Torí náà, bí wọ́n bá ti dá ifá, tí odù ifá sì jẹ yọ lójú ọpọ́n tàbí tí ó hù, ó di dandan kí wọ́n padà sí inú ìtàn ìwáṣẹ̀ tí ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ti kọ́kọ́ ṣẹlẹ̀. Ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ẹsẹ ifá máa ń sábàá sọ nípa ẹnìkan tí ó lọ ṣàyẹ̀wò lọdọ̀ babaláwo kan nítorí ìṣòro kan tí ó ní. Òhun tí babaláwo tí ó kọ́kọ́ ki ẹsẹ odù ifá náà ní kí ẹni tí a kọ́kọ́ kì í fún ṣe ni àṣẹ tí ifá yóò pa fún ẹni tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ wá ṣàyẹ̀wò lójú ayé lọ́dọ̀ babaláwo òde òní. Èyí wá já sí pé ẹni tí ó wá dífá nínú ìtàn ìgbà ìwáṣẹ̀ ni ó máa ń dúró gẹ́gẹ́ bí àrokò ìtọ́sọ́nà fún ẹni tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ wá dífá lójú ayé, níwọ̀n ìgbà tí ìṣòro wọn ti bá ara wọn mu tàbí tí ó jọra wọn. Gbogbo ohun ẹbọ tí ẹ̀dá inú ìtàn, tí a kọ́kọ́ ki ifá yìí fún rú ni yóò jẹ́ ohun ẹbọ fún ẹni tó ṣẹ̀ṣẹ̀ wá ṣàyẹ̀wò náà. Ní ìgbà mìíràn, àwọn ìtàn wọ̀nyí kì í ju ẹyọ kan lọ nínú ẹsẹ ifá kékeré. Bí ó bá jẹ́ ẹsẹ ifá ńlá ni, a le bá ìtàn tó ju ẹyọ kan lọ pàdé níbẹ̀. Àwọn ẹsẹ ifá mìíràn a máa sọ ìtàn àwọn òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀, ìtàn ìlú tàbí ìtàn àwọn ẹranko oríṣìíríṣìí. Nípa àlàyé àwọn kókó tó wà nínú ẹsẹ ifá ni ìtàn ṣe máa ń jẹ yọ. Èyí ló mú kí àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ kan gbà pé ìlànà ewì nìkan kọ́ ni ó yẹ kí á fi máa ṣe ìdàkọ ẹsẹ ifá sílẹ̀ sínú ìwé. Ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀ ní ó máa ń ní bátànì ewì nígbà tí ààrín rẹ̀ máa ń sábàá jẹ́ ìlànà ọlọ́rọ̀ geere, nítorí ìtàn

sísọ àti àlàyé ṣíṣe ní í máa wà níbẹ̀, ìparí a sì tún máa jẹ́ ìlànà ewì, nítorí àtúnwí ìbẹ̀rẹ̀ àti orin ni ó máa ń jẹ́. Ju gbogbo rẹ̀ lọ bí babaláwo tí ó kifá bá ṣe kì í ni ó yẹ kí á dà á kọ sílẹ̀ sínú ìwé.

### 4.2.2 Ètò Inú Ẹsẹ Ifá

Láti dá ẹsẹ ifá mọ̀, ó ní àwọn àbùdá kan tó jẹ́ pé a kò le bá pàdé nínú ewì alohùn Yorùbá mìírán yàtọ̀ sí ẹsẹ ifá. Àwọn àbùdá wọ̀nyí a máa wà létò débi pé níṣísẹ̀ntẹ̀lé ni wọ́n máa ń jẹyọ tẹ̀ lé ara wọn. Bí babaláwo kan bá gbé àbùdá kan ṣíwájú ọ̀kan nínú àwọn àbùdá yìí, arúmọjẹ babaláwo ni àwọn yòókù yóó kà babaláwo bẹ́ẹ̀ sí; wọ́n le ní kò gbọ́fá. Àwọn ètò tí ó sábàá máa ń jẹyọ nínú ẹsẹ ifá gẹ́gẹ́ bí àbùdá ẹsẹ ifá nìyí;

1. Ìkansárá sí babaláwo (tàbí: oríkì/ìnagijẹ/ orúkọ babaláwo tó kọ́kọ́ kifá náà nígbà ìwáṣẹ̀)
2. Ẹni tí a dífá fún àti ìdí tí a fi dífá fún un (orúkọ oníbàárà/ òǹdáfá; ẹni tí ó wá dífá)
3. Àṣẹ ifá (ohun tí ifá ní kí oníbàárà ó ṣe)
4. Ohun tí ẹni tí ó wá dífá ṣe nípa àṣẹ ifá (bóyá ó ṣe é tàbí kò ṣe é)
5. Àyọrísí ohun tí ẹni tí ó wá dífá ṣe (yálà sí rere tàbí sí búburú)
7. Àwítúnwí àwọn ìgbésẹ̀ ìṣáájú (pàápàá jùlọ, ìgbésẹ̀ kìíní sí ìkẹta)
8. Àgbálọgbábọ̀ (akíyèsí gbogbogbòò, ìpèdè láti fi bí àṣẹ ifá ṣe lágbára tó hàn tàbí ẹ̀kọ́ tó súyọ)

A ó fi àpẹẹrẹ gbe àwọn ètò inú ẹsẹ ifá òkè yìí lẹ́sẹ̀ láti inú ẹsẹ ifá Ọ̀yẹ̀kú méjì tí ó ní gbogbo àwọn ìgbésẹ̀ náà.

1. Ìrì dá, ìrì so;  
   Ìrì jí ní kùtùkùtù so lébélèbèlébé;
2. A díá fún ìrìwọ̀wọ̀  
   Tí ó ṣọkọ Atóórọ̀mọ̀lá
3. Nwọ́n ní ó káakì MọlẹÓ jàre,Ẹbọ ní ó ṣe.
4. Ó gbọ́ rírú ẹbọ, ó rú,Ó gbọ́ èrù àtùkèṣù, ó tù,Ó gbọ́ ìkarara ẹbọ hà fún un.
5. Ó wá ń yin àwọn awoo rẹ̀,

   Àwọn awo rẹ̀ ń yin Ifá.  
   Àgogo ní Ìporó,  
   Àràn ní Ìkijà,  
   Ọ̀pá kugúkugù lójúde Ìṣẹrimọgbe.  
   Ó ya ẹnu kótó,  
   Orin awo ló bọ́ sí i lẹ́nu.

6. Ó ní ìrì dá, ìrì so,

   Ìrì jí ní kùtùkùtù so lébélèbèlébé;  
   A díá fún Ìrìwọ̀wọ̀

Tí ó ṣọkọ Atóórọ̀mọ̀lá
7. Ìrì dá o,
Ìrì so,
Ìrì ò bá dúó,

O gbAtòórọ̀. Àbímbọ̀lá, 2014: 33)

Gẹ́gẹ́ bí ni a ṣe nọ́ńbà àpẹẹrẹ ẹsẹ ifá òkè yẹn, ẹnu ibi tí a fi “1” sàmì sí lókè yẹn ni “Ìkansárá sí babaláwo (tàbí orúkọ babaláwo tó kọ́kọ́ dífá náà nígbà ìwáṣẹ̀)” nínú ẹsẹ ifá náà. Láìṣe àní àní irú ìpèdè tí babaláwo ìgbà ìwáṣẹ̀ náà máa ń sọ ni wọ́n fi dípò orúkọ rẹ̀ yìí. Ẹnu ibi tí a fi “2” sàmì sí ni orúkọ oníbààrà àti ohun tó wá dífá sí wà. Ìgbésẹ̀ kẹta tí a fi “3” sàmì rẹ̀ ni “Àṣẹ ifá (ohun tí ifá ní kí oníbààrà ó ṣe)”, “4” ni ìgbésẹ̀ “Ohun tí ẹni tí ó wá dífá ṣe nípa àṣẹ ifá (bóyá ó ṣe é tàbí kò ṣe é)”. Nínú ẹsẹ ifá yìí, ìrìwọ̀wọ̀ ṣe ohun tí ifá ní kó ṣe. Èyí ló fà á tí àyọrísí ẹbọ tó rú náà fi jẹ́ ijó àti ayọ. Èyí sì ni “Àyọrísí ohun tí ẹni tí ó wá dífá (òǹdáfá) ṣe, tí ó jẹ́ ìgbésẹ̀ karùn-ún (5). Ayọrísí yìí máa ń já sí rere bí òǹdáfá bá gbọ́ràn sí ifá lẹ́nu, bí àpẹẹrẹ Ìrìwọ̀wọ̀ nínú ẹsẹ ifá tí a fi ṣe àpẹẹrẹ, ó sì lè já sí àbámọ̀ bí òǹdáfá bá ṣàìgbọràn, tí ó kọtí ọ̀gbọin sí àṣẹ tí ifá pa.Ìgbésẹ̀ kẹfà ni “Àwítúnwí àwọn ìgbésẹ̀ ìṣáájú (pàápàá jùlọ, ìgbésẹ̀ kìíní sí ìkẹta)” tí a fi nọ́ńbà “6” sàmì. Ìgbésẹ̀ keje ni “Àgbálọgbábọ̀ (akíyèsí gbogbogbòò, ìpèdè láti fi bí àṣẹ ifá ṣe lágbára tó hàn tàbí ẹ̀kọ́ tó súyọ)” tó gba nọ́ńbà “7”.

## 4.3.0 Ọfọ̀

Ewì àwíṣẹ ni ọfọ̀. Agbára ọ̀rọ̀ ẹnu àwọn Yorùbá ni ọfọ̀. “fọ̀” ni ọ̀rọ̀ iṣe ìpìlẹ̀ árá náà. Èyí ni a fi mọ́fíìmù ìṣẹ̀dá /ọ-/ sọ di orúkọ (ọfọ̀). Bí a bá wo ìtumọ̀ ìdúrófún ọ̀rọ̀ yìí, ohun tí ó túmọ̀ sì ni pé ohun tí a máa ń sọ. Ohun tí ó jẹ́ ká wí báyìí ni pé “fọ̀” ni ọ̀rọ̀ mìíràn tí a le fi túmọ̀ “sọ”. Yorùbá gbà pé àwọn ẹ̀mí àìrí kan wà tí wọ́n ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú ènìyàn. Àwọn ẹ̀mí àìrí wọ̀nyí ní orúkọ àṣírí, nínú ọfọ̀ ni a ti le bá wọn pàdé, a sì le pe àwọn ẹ̀mí àìrí wọ̀nyí níwọ̀n ìgbà tí a bá ti mọ orúkọ wọn fún ìrànlọ́wọ́. Yàtọ̀ sí èyí, Yorùbá gbà pé àwọn ìpèdè àṣírí kan wà, tí àwọn tí ó bá mọ̀ wọ́n maa ń lò láti múnǹkan ṣẹ ní wàràǹṣeṣà. Bí ènìyàn bá mọ àwọn ọ̀rọ̀ àṣírí wọ̀nyí, olúwarẹ̀ le lò wọ́n láti mu ìfẹ́ inú rẹ̀ ṣẹ nítorí pé àwọn ọ̀rọ̀ náà jẹ́ ọ̀rọ̀ àṣẹ. Yàtọ́ sí èyí, Yorùbá tún ka ọfọ̀ sí oríkì ewé, egbò àti àwọn ohun èlò tí a fi ń ṣe òògùn, èyí tí ó le mú òògùn ṣẹṣẹ́ ní wàràǹṣeṣà bí a bá ki oríkì àwọn ohun èèlò òògùn wọ̀nyí. Oríṣiríṣi ọfọ̀ ni ó wà, a ní ọ̀fọ̀ orí fífọ́, ọfọ̀ inú rírun, ọfọ̀ oró ejò, ọfọ̀ oró àkekèé, ọfọ̀ oró ìbọn, ọfọ̀ afòràn, ọfọ̀ mádàáríkàn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ọfọ̀ kan wà tó jẹ́ pé apọfọ̀ nílò láti jẹ ohun kan tàbí kí ó tọ́ ohun kan lá kí ó tó máa pè wọ́n. Lára ohun tí apọfọ̀ lè jẹ tàbí tọ́ lá ni orógbó, ataare, àdí, epo àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Bí a bá wo oríṣìíríṣìí ọfọ̀ tí a ní, lára wọn àbùdá àdání ọfọ̀ wọ̀nyí ni: apè, gbólóhùn máyẹ̀, ìfọ̀rọ̀dárà alárokò àti iṣẹ́ tí a fẹ́ kí ọfọ̀ jẹ́.

### 4.3.1 Apè

Nígbà tí bá ń pe ẹni tàbí ohun kan tí kò sí ní tòsí ẹni tó ń pè é, ní ìrètí pé ohun tàbí ẹni tí à ń pè náà máa dáni lóhùn. Àpapọ̀ àwọn orúkọ tí fi pè ẹ̀mí àìrí tí a fẹ́ rán níṣẹ́ ni apè. Yorùbá gbà pé kò sí ohun tí Ẹlẹ́dàá dá, tí kò ní orúkọ tirẹ̀. Yàtọ̀ sí orúkọ tí gbogbo enìyàn mọ̀ mọ àwọn iṣẹ́ ọwọ́ Ẹlẹ́dàá ń jẹ́, àwọn orúkọ kan wà tó jẹ́ pé orúkọ àṣírí ni wọ́n, kì í ṣe gbogbo ènìyàn ni ó mọ̀ wọ́n. Àwọn àgbà ọ̀mọ̀ràn ni ó máa ń mọ̀ wọ̀n, wọ́n máa ń jẹyọ nínú ọfọ̀ ní ipò ìbẹ̀rẹ̀ ọfọ̀ pípè náà, níbi tí ó bá ti wáyé. Àkíyèsí kan tí a nílò láti ṣe ní ìhín ni pé kì í ṣe gbogbo ọfọ̀ ni ó máa ń ní apè. Jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ yìí:

1. Adísúúrúgbẹ̀jẹ́

   Adísúúrúgbẹ̀jẹ́
   Adísúúrúgbẹ̀jẹ́
   Ẹkùn-abàyà-gbàá
   Ẹkùn-abàyà-gbàá
   Ẹkùn-abàyà-gbàá
   Àtẹ́wọ́-ni-yagayagà-fií-gbọrẹ-lọ́ọ́-Olódùmarèè
   Àtẹ́wọ́-ni-yagayágà-fií-gbọrẹ-lọ́ọ́-Olódùmarèè
   Adísúúrúgbẹ̀jẹ́, Ẹkùn-abàyà-gbàá loúkọ tà á pefá
   Àtẹ́wọ́-ni-yagayagà-fií-gbọrẹ-lọ́ọ́-Olódùmarèloúkọ
   tà ápẹ̀yin Èṣù Ọ̀dàrà
   Olúkúmèsé lorúkọ tà á pẹ̀yin ìyà mi àjẹ́
2. Ẹ súré tete wá, ẹ wá là mí o o
   Ẹ súré tete wá, ẹ wá gbè mí
3. Gẹ̀gẹ̀ ladìẹ í kẹ́yin adìẹ
   Gẹ̀gẹ̀ ladìẹ í kẹ́yinin rẹ̀
   Gẹ̀gẹ̀ ladìẹ í kẹ́yin rẹ̀
   Bádìẹ bá ń sunkún aṣọ
   Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ùhùhù lOlódùmarè fií bò ó o o

4. Ifá, ó tó gẹ́gẹ́ kọ́ ọ wá po
   ko ajé bò mí
   Ifá, ó tó gẹ́gẹ́ kọ́ ọ wá poko aya bò mí
   Ifá, ó tó gẹ́gẹ́ kọ́ ọ wá poko ọmọ bò mí
   Ifá, ó tó gẹ́gẹ́ kọ́ ọ wá poko ohun rere bò mí

5. Bádìẹ ń bá ńsunkún aṣọ
   Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ùhùhù lOlúdùmarè í fií bò ó o o(Ọlátúnjí, 1984: 125)

Àbùdá tó jẹyọ nínú ọfọ̀ òkè kì í ṣe ẹyọkan, ṣùgbọ́n ohun tí ó jẹ wá lógún níbí ni ègé kìíní àyọlò náà. Apè ni ègé kìíní (1) inú àyọlò yìí. Ẹ̀ẹ̀mẹta ni apọfọ̀ pe Adísúúrúgbẹ̀jẹ́ ní ìbẹ̀rẹ̀, lẹ́yìn èyí ni ó pe Ẹkùn-abàyà-gbàá náà ní ẹ̀ẹ̀mẹta. Ó tẹ̀ sí iwájú láti pe Àtẹ́wọ́-ni-yagayagà-fií-gbọrẹ-lọ́ọ́-

Olódùmarèè ní ẹ̀ẹ̀mejì kí ó tó wá sọ pé orúkọ mìíràn fún Ifá ni Adísúúrúgbẹ̀jẹ́ àti Ẹkùn-abàyà-gbàá tí òun ń pè. Ó tún fi kún un pé Àtẹ́wọ́-ni-yagáyagà-fií-gbọrẹ-lọ́ọ́-Olódùmarèè jẹ́ orúkọ mìíràn fún Èṣù Ọ̀dàrà. Ní ìparí ègé yìí ni apọfọ̀ sọ pé Olúkúmèsé lorúkọ tí wọ́n ń pe àwọn àjẹ́. A ó rí i pé níṣe ni apọfọ̀ ń pe orúkọ àṣírí àwọn tí a mọ orúkọ gbajúgbajà wọn (Ifá, Èṣù Ọ̀dàrà àti Àjẹ́). Láti jẹ́ kí ó yéni pé òun mọ orúkọ àwọn ẹ̀mí náà ni a lérò pé ó tún fi yànàná àwọn orúkọ tí ó ń pè náà. Ó fi hàn pé òun kò mú òmúlómùú.

## 4.3.2 Gbólóhùn Máyẹ̀

Torí pé àṣẹ ni àwọn ìpèdè inú ọfọ̀ ni gbólóhùn máyẹ̀ fi jẹ́ àbùdá kan pàtàkì fún ọfọ̀. Gbólóhùn máyẹ̀ ni gbólóhùn tó jẹ́ pé òye òtítọ́ inú rẹ̀ kò le ṣàìrí bẹ́ẹ̀. Ìdí abájọ nìyí tí a fi pè é ní máyẹ̀. Ọ̀nà mẹ́ta pàtàkì ni gbólóhùn máyẹ̀ le pín sí nínúọfọ̀. Nínú àpẹẹrẹ wa òkè, ìgbésẹ̀ kẹta (3) àti ìkarùn-ún (5) inú ọfọ̀ náà ni gbolóhùn máyẹ̀. Oríṣi gbólóhùn mẹ́tà tí a máa ń fi ṣe ìgbékalẹ̀ gbólóhùn máyẹ̀ nínú ọfọ̀ ni gbólòhùn ìjẹ́-hẹn, gbólóhùn àyísódì àti gbólóhùn ká-ní. Gólóhùn máyẹ̀ oníjẹ̀ẹ́-hẹn ni a fi ń sọ bí nǹkan ti máa ń rí ní gbogbo ìgbà. Wúrẹn "ni" ni atọ́ka gbólóhùn ìjẹ́-hẹn nínú ọfọ̀ Yorùbá.Gbólóhùn máyẹ̀ oníjẹ̀ẹ́-hẹn ni àwítùnwí ìpèdè mẹ́ta àkọ́kọ́ inú ìgbésẹ̀ kẹta àpẹerẹ tí a ṣe lókè yẹn, níbi tí a ti sọ pé "Gẹ̀gẹ̀ ladìẹ í kẹ́yinin rẹ̀". Àpẹ̀ẹrẹméjì mìíràn tún nìyí:

1 Agbe ní í gbére kOlókun  
Àlùkò ní í gbére é kỌlọ́sà  
Odídẹrẹ́ ... níí gbére é kOlúwòó (Ajàyí 2014: 130)

2 Orí lẹja fi í labú;  
Orí lapọ́nrán fi í làrókò;  
Orí lòpó fi í tilẹ̀;  
Orí lewúrẹ́ fi í jalé;  
Orí làgbò fí í jàjààgbulà; .... (Ajàyí 2014: 112)

Gbolóhùn máyẹ̀ oníjẹ̀ẹ́-hẹn ni àwọn àpẹẹrẹ yìí náà nítorí pé wọ́n fi òye èrò bí nǹkan ti ń rí hàn. Nínú àpẹẹrẹ tí a kọ́kọ́ tọ́ka sí àti àwọn èyí tí aṣẹ̀ṣẹ̀ ṣe yìí, a rí ìfarahànwúnrẹ̀n "ni",ti ó jẹ́ atọ̀ka gbólóhùn ìjẹ́-hẹn. Ó yẹ kí á tọ́ka sí i pé ìró /n/ inú "ni" yìí ni ó yíra padà di /l/ nínú "ladìẹ","lẹja", "lapọ́rán" àti "lòpó""lewúrẹ́" àti "làgbò" tí ó jẹyọ nínú àwọn àpẹẹrẹ náà (ni + adìẹ > *nadìẹ > ladìẹ; ni + ẹja . *nẹja > lẹja; ni + apọ́nran>*napọ́nran>lapọ́nran; ni + òpó> *nòpó> lòpó; ni + ewúrẹ́> *newúrẹ́ > lewúrẹ́; ni + àgbò > *nàgbò > làgbò.)Lẹ́yìn tí ìpajẹàti ìsúnkì wáyé, bí aṣe fi hàn nínú akámọ́ tí a ṣe yẹn, ni àwọn ọ̀rọ̀ tuntun náà tó jẹyọ. Fáwẹ́lì aránmúpè /in/ tí ó wà níwájú "ni" ni ó di pípajẹ tí àwọn fáwẹ́lì àìránmúpè /a/, /ẹ/, /a/, /ò/ /e/ àti /à/ wá kágun sí kọ́ńsónáǹtì /n/. Bí irú èyí bá wáyé nínú èdè Yorùbá kọ́ńsónáǹtì /n/ gbọ́dọ̀ yí padà sí ẹ̀dà àìránmúpè rẹ̀ /l/ gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣẹlẹ̀ nínú àwọn ọ̀rọ̀ tuntun tó jẹyọ yẹn. Kọ́ńsónáǹtì /n/ kì í wáyé ṣaájú fáwẹ́lì àìránmúpè nínú èdè Yorùbá

àjùmọ̀lò. Ìdí nìyẹn tí a fi fi àmì ìràwọ̀ sí "*nadìẹ", '*nẹja", "*napọ́rán""nòpó", newúrẹ́ àti "*nàgbò"nínú àfihàn ètò ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí a ṣe sínú àkámọ́, láti tọ́ka sí i pé a kì í sọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀. Ó ṣe é ṣe láti tún ọfọ̀ 2òkè yẹn kọ kí á le fi àtọ́ka gbólóhùn ìjẹ́hẹn náà hàn gbangba bí èyí:

Orí ni ẹja fi í labú;
Orí ni apọ́nrán fi í làrókò;
Orí ni òpó fi í tilẹ̀;
Orí ni ewúrẹ́ fi í jalé;
Orí ni àgbò fí í jàjààgbulà; ....

Òdìkejì gbólóhùn ìjẹ́-hẹn ni gbólóhùn àyísódì. Èyí jẹ́ gbólóhùn tó fi òye ohun tí kò ṣe é ṣe hàn, tàbí bí nǹkan kì í tí rí. Atọ́ka gbólóhùn àyísódì nínú ọfọ̀ ni "kì í." Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

1. Iràn oṣó kan kì í jọṣẹ
   Ìran àjẹ́ kan kì í jèèpo ọ̀bọ̀
   Àwọn ìyàmi ẹlẹyẹ, wọn kì í jèédú
   Àjẹ́ ayé kan kì í gbójúgbójú
   Kó pọmọ àjẹ́ ọ̀run jẹ...

2. Àánú ojú
   Kì í jẹ́ ká fọwọ́ bọjú
   Àánú epo
   Kì í jẹ́ ká sọ àkàrà nù;
   Àánú ẹkùn;
   Kì í jẹ́ ká sun awọ ẹkùn jẹ.... (Ọlábímtán, 1988: 3)

Nínú àyọlò òkè kìn-ín-ní, apọfọ̀ fẹ́ kó yé wa pé bí ó ṣe le wù kí ó rí, oṣó kò ní í jẹ ọṣẹ, bákan náà ni pé àjẹ́ kan kò ní í jẹ èèpo ọ̀bọ̀. Àwọn àjẹ́ náà ni apọfọ̀ pè ní àwọn "ìyàmi ẹlẹyẹ." Apọfọ̀ jẹ́ kí á mọ̀ pé wọn kò gbọdọ̀ jẹ èédú. Èyí jẹ́ gbólóhùn àyísódì, tí òye ọ̀rọ̀ ìṣe inú rẹ̀ "kò gbọdọ̀ rí bẹ́ẹ̀." Bákan náà nínú àyọlò kejì, àwọn awẹ́gbólóhùn kejì inú ìbádọ́gbà gbólóhùn oníla-méjìméjì mẹ́tẹ̀ẹ̀ta, tí wọ́n tẹ̀léra,tún ń fi òté lé e pé àwọn ohun tí akéwì sọ sínú ọ̀wọ́ àwọn gbólóhùn àkọ́kọ́ kò le di òtítọ́.

Àtọ́ka "kì í" tí ó lò ló fi èyí hàn gbangba.

Oríṣìí ẹ̀yà gbólóhùn máyẹ̀ kẹta ni gbólóhùn "kání." Èyí ni gbólóhùn tí a ti máa ń sọ pé "Bí ohun kan bá ṣẹlẹ̀ bákan, ohun báyìí báyìí ni yóò jẹ́ àyọrísí rẹ̀." Atọ́ka gbólóhùn "kání" tó wọ́pọ̀ nínú ọfọ̀ ni "Bí ... bá ...". Ẹ jẹ́ kí á wo àwọn àpẹẹrẹ yìí:

1. Bádìẹ ń bá ńsunkún aṣọ
   Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ùhùhù lOlúdùmarè í fií bò ó (Ọlátúnjí 1984: 125)

2. Bí ọmọdé bá dárí sapá, apá a pa á,

Bí ọmọdé bá dárí sọ̀rókò, ìrókò a kò ó,
Bí ọmọdé bá dárí sọ orúrù, oko là á ti í rùkú ẹ̀ wálé (Fábùnmi, 1972)

3. Bẹ́yẹlé bá jí

Ẹyẹlé a fapá fare owó wọlé,
...
Bálùkò bá jí
A ṣaṣọ rẹ̀ lósùn rẹ̀rẹ̀.
...
Bí lékèélékèé bá jí,
A ṣaṣọ rẹ̀ ní kìkì ẹfun....(Ọlábímtán, 1988: 2)

Méjìméjì ni àwọn òye ọ̀rọ̀ inú gbólóhùn ká-ní àyọlò òkè wọ̀nyẹn rìn. Abala àkọ́kọ́ ni a ti rí awẹ́ gbólóhùn alátọ́ka ká-ní nígbà tí abala kejì jẹ́ gbólóhùn tó sọ àyọrísí awẹ́ gbólóhùn alátọ́ka ká-ní. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, "Bí ọmọdé bá dárí sapá..." ni awẹ́gbólóhùn alátọ́ka ká-ní. Gbólóhùn tó sọ àyọrísì gbólóhùn alátọ́ka ká-ní yìí ni "...apá a pa á." Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú gbólóhùn yìí kì í ṣaláì má rí bẹ́ẹ̀, bí apá kìn-ín-ní bá fi le ṣẹlẹ̀, dandan ni kí apá kejì, tó jẹ́ àyọrísì ìṣẹ̀lẹ̀ inú apá kìn-ín-ní yẹn ṣẹlẹ̀ tẹ̀lé e. Ẹyẹ kì í fi apá kan fò ni ọ̀rọ̀ wọn. Wọn jìjọ máa ń rìn pọ̀ ni.

### 4.3.3 Iṣẹ́Tí aFẹ́kí Ọfọ̀ jẹ́

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ní òkè, ìfẹ́ inú apọfọ̀ ni ìdí pàtàkì tí 'o fi ń pọfọ̀.Nígbà tí apọfọ̀ bá ti ké sí àwọn ẹ̀mí àìrí tí ó ni orúkọ àṣírí tí ó pè, tí ó sì ti sọ ìdí tí àwọn ohun tí òun fẹ́ wí fi gbọdọ̀ rí bẹ́ẹ̀ tàbí tí kò gbọdọ̀ fi rí bẹ́ẹ̀, ohun tí ó kù ni kí apọfọ̀ sọ ohun tí ó fẹ́ kí àwọn ẹ̀mí àìrí yìí bá òun ṣe. Èyí ni a pè ní ìfẹ́ inú apọfọ̀. Àpẹẹrẹ tó jẹ yọ nínú àyọlò tí a mú wà lókè nìyí:

Ifá, ó tó gẹ́gẹ́ kọ́ ọ wá poko ajé bò mí
Ifá, ó tó gẹ́gẹ́ kọ́ ọ wá poko aya bò mí
Ifá, ó tó gẹ́gẹ́ kọ́ ọ wá poko ọmọ bò mí
Ifá, ó tó gẹ́gẹ́ kọ́ ọ wá pokoohun rere bò mí (Ọlátúnjí, 1984:125)

Apọfọ̀ nínú àyọlò yìí fẹ́ kí Ọ̀rúnmìlà (Ifá) ó wá wá iré owó (ajé), aya, ọmọ àti fún ohun rere gbogbo fún òun. Kò sí òkè ìṣòro tí a kò le pọ̀fọ̀ láti wá ìyanjú sí. Ó le jẹ́ ìṣẹ́gun ọ̀tá, àṣejèrè lórí òwò, ààbò, ọ̀wọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

### 4.3.4 Ìfọ̀rọ̀dárà Alárokò

Ìfọ̀rọ̀dárà alárokò a máa wáyé nínú ọfọ̀ nígbà tí á bá ṣàmúlò àwọn ọ̀rọ̀ orúkọ kan ní ipò olùwà nínú gbólóhùn papọ̀ mọ́ àwọn ọ̀rọ̀ ìṣe tí wọ́n ní ìrísí kan náà pẹ̀lú ó kéré tán, abala ọ̀rọ̀ orúkọ tí ó jẹ́ olùwà náà lọ́nà tí yóò fi wá dà bí ẹni pé níṣe ni a fa ọ̀rọ̀ ìṣe náà yọ látiinú ọ̀rọ̀ orúkọ tí ó jẹ́ olùwà yẹn. Bí àpẹẹrẹ,

Kúlú**sọ** ló ní kó máa **sọ** sími nínú
I**yọ̀** lóní kó máa **yọ̀** sí mi lọ́kàn gẹ̀ẹ̀rẹ̀gẹ̀
Àpẹẹrẹ mìíràn tí a ti mẹ́nu bà lókè ni:

Bí ọmọdé bá dárí sapá, a**pá** a **pa á**
Bí ọmọdé bá dárí sọ̀rókò, ìró**kò** a **kò ó**
Bí ọmọdé bá dárí sọ orú**rù**, oko là á ti í **rùkú** ẹ̀ wálé (Fábùnmi, 1972)

Bí a bá wo ìtumọ̀ àwọn àpẹẹrẹ yìí, níṣe ni ó dàbí ẹni pé kúlúsọ,àti iyọ̀ní agbára láti mú kí nǹkansọ síni nínú, kí ó sì yọ̀ síní lọ́kàn. Bákan náà ni àwọn igi apá àti ìrókò,tí a dárúkọ nínú àpẹẹrẹ kejì, ní agbára láti pa, àti láti ko ẹni tí ó bá dárí sọ wọ́n, tí igi orúrù náà sì ní agbára láti jẹ́ kí wọ́n ru òkú ẹni tí ó bá dárí sọ ọ́ wálé láti oko. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ní ó jẹ́ pé díẹ̀ lára àwọ èròjà tí a dárúkọ nínú ọfọ̀ báyìí máa ń wà lára òògùn tí apọfọ̀ yóò sà. Agbára àṣírí tí àwọn Yorùbá nígbàgbọ́ pé ó wà lára àwọn èròjà wọ̀nyí ni ó ń mú kí wọ́n fi wọ́n ṣe òògùn tí wọ́n ń pe ọfọ̀ sí.Kò sí àní àní kankan wí pé ìfọ̀radarà inú ọfọ̀ jẹ́ èyí tí wọ́n fi ń parokò nípa agbara àìrí tí ó wà nínú àwọn èròjà òògùn tí wọ́n ń sà.

Ní ìparí, ó yẹ kí á tọ́ka sí i pé ọfọ̀ náà ni àwọn Yorùbá ń pè ní ògèdè. Àwọn kan gbà pé ọfọ̀ tó le gan-an ni ògèdè jẹ́. Àwọn mìíràn sì gbà pé ìgbà tí apọfọ̀ méjì bá jọ ń fi ọfọ̀ ta kànǹgbọ̀n, tí wọ́n ń bi ara wọn leèrè ohun ìjìnlẹ̀ tí ó rọ̀ mọ́ ìtàn ìwáṣẹ̀tí ó fara sin, tí ó sì jẹ mọ́ ọfọ̀ ni wọ́n ń pe ògèdè. Èyí tó wù kó jẹ́, orúkọ mìíràn tí a tún le pe ọ̀fọ̀ ni ògèdè. Ó ṣé é ṣe kí ọfọ̀ jẹyọ nínú ẹsẹ ifá àti àwọn ewì àrángbọ̀ mìíràn. Ọfọ̀ tún máa ń jẹyọ nínú àwọn ìṣàré Yorùbá bí ìjálá, ẹ̀ṣà egúngún, ẹkún ìyàwó, Ṣàngó pípè, Ọyà pípè, Èṣù pípè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.Kò sí àní àní pé ewì àmúṣagbára ni ọfọ̀. Oríṣi ewì àmúṣagbára mìíràn ni àyájọ. Inú ọfọ̀ tí ìtàn ìwáṣẹ̀ bá ti jẹ yọ ni ayájọ. Gbogbo ẹsẹ ifá tí ó bá ní ọfọ̀ nínú máa ńjẹ́ àyájọ́ nítorí ìtọ́ka sí ìtàn kan tàbí èkejì kò lè ṣàì jẹyọ níbẹ̀.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣàlàyé ohun tí oríkì, ẹsẹ ifá àti ọfọ̀ jẹ́. A ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdádíẹ̀ díẹ̀ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

- Àwọn àbùdá oríkì tí a yẹ̀ wò ni, àwọnọ̀rọ̀ tí a sọdorúkọ, àwọn ọ̀rọ̀ ìtọ́kasẹ́bí/ìran àti pípe ẹnìkan ṣoṣo ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ orúkọ.
- Àwọn àbùdáẹsẹ ifá tí a gbé yẹ̀wò ni, ìtàn sísọ àti àwọn ìgbésẹ̀ ètò ìhun rẹ̀ wọ̀nyí: ìkansárá sí babaláwo, ẹni tí a dífá fún àti ìdí tí a fi dífá fún un, àṣẹ ifá, ohun tí ẹni tí ó wá dífá ṣe nípa àṣẹ ifá, àyọrísí ohun tí ẹni tí ó wá dífá ṣe, àwítúnwí àwọn ìgbésẹ̀ ìṣáájú àti àgbálọgbábọ̀.
- Àwọn àbùdá ọfọ̀ tí a jíròrò lé lórí ni apè, gbólóhùn máyẹ̀ àti ìṣẹ́ tí a fẹ kí ọfọ̀ jẹ́ pẹ̀lú ìfọ̀rọ̀dárà alárokò.

- A kò sì ṣàìsọ̀rọ̀ díẹ̀ díẹ̀ nípa ìwúlò àwọn ewì àrángbọ́ náà.

Ohun tí a kò gbọdọ̀ gbàgbé ni pé, ó ṣe é ṣe kí gbogbo àwọn irúfẹ́ ewì àrángbọ́ kíkún wọ̀nyí jẹ yọ nínú ara wọn. Ìyẹn ni pé ọfọ̀ lè jẹyọ nínú ẹsẹ ifá (àyájọ́). Bákan náà, ọfọ̀ le jẹ yọ nínú oríkì náà. Bí ọfọ̀ ṣe le jẹyọ nínú oríkì náà ni oríkì le jẹ yọ nínú ọfọ̀. Kò sí àní àní pé oríkì àwọn èròjà tí a fi ṣe òògún máa ń jẹyọ nínú ọfọ̀. Oríkì a máa jẹyọ nínú ẹsẹ ifá náà. Oríkì àwọn odù tó jẹyọ lójú ọpọ́n ifá ni ẹsẹ ifá jẹ́. Kíkì ni àwọn babaláwo sì máa sọ pé wọn ń ki odù ifá nígbà tí wọ́n bá ń dáfá. Bákan náà sì ni ìjẹyọ-nínú-ara tàbí ìwọnúbọnú máa ń wayé dáadaá láàrín àwọn ìsọ̀rí ewì àrángbọ́ kéékèké àti àrángbọ́ ńlańla. òwe lè jẹyọ nínú ẹsẹ ifá, kí ẹsé ifá sjẹyọ nínú òwe, àrọ̀ páápàá a máajẹyọ nínú oríkì pàápàá oríkì orílẹ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ṣe àlàyé àwọn àbùdá oríkì Yorùbá méjì tí ó wù ọ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ tí ó péye.
2. Ìgbésẹ̀ mélòó ni ó lérò pé ó wà nínú ìhun ẹsẹ ifá? Lo ẹsẹ ifá kan yàtọ̀ sí èyí tí a ti lò nínú ìdánlẹ́kọ̀ọ́ yìí láti ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn ìgbẹ́sẹ̀ náà.
3. a.)Kín ni gbólóhùn máyẹ̀ nínú ọfọ̀? b.)Mélòó ni irúfẹ́ ìhun gbolohùn náà? d.) Lo àpẹẹrẹ méjì méjì, ó kéré tán, láti ṣe àlàyé ìgbékalẹ̀ irúfẹ́ àwọn gbólóhùn máyẹ̀ kọ̀ọ̀kan.
4. Ṣe àlàyé ìwúlò àwọn ewì àrángbọ́ kíkún tí a gbé yẹ̀wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Abímbọ́lá, W. 2014. *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá: Apá Kìn-ín-ní,* University Press Plc. Ìbàdàn. Àkọ́gbéjáde,1968, Collins, Glasgow.

Àrẹ̀mú, A. 1975.*Àṣàyàn Oríkì (Ońjẹ, Ohun - Ọ̀gbìn, Èèrà, Ẹyẹ, Ẹranko, Àti Ejò),* Oxford University Press,Ìbàdàn

Aróhunmọ́làṣẹ, O. 1987. *Àgbéyẹ̀wò Ìdàgbàsókè: Èdè àti Àkọtọ́ Yorùbá Láti Ọdún 1800 sí 1985.* Oníbọnòjé Press and Book Industries (Nig.) Ltd. Ìbàdàn.

Àjàyí, Bádé 2014. *Ọfọ̀:The Yorùbá Incantation (A Text Linguistics Exploration Analysis),* Chridamel Publishing House, Ìlọrin.

Babalọla, A. 2001.*Àwọn Oríkì Orílẹ̀ Mẹ́tàdílọ́gbọ̀n,* Longman Nigeria Plc., Ìbàdàn.

Babalọlá, A. 1975. *Àwọn Oríkì Bọ̀rọ̀kìnní,*Hodder and Stoughton Educational,London.

Bascom W. 1969. *Ifá Divination: Communication Between Gods and Men in West Africa*,Indiana University Press, Bloomington.

Fábùnmi, M. A. *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ifẹ̀*, Oníbọnòjé Press, Ìbàdàn.

Ògúndèjì, P.A. (1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. Centre for External Studies, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Ọlábímtán, A. 1988. *Àkójọpọ̀ Ewì Àbáláyé àti Ewì Àpilẹ̀kọ*, Paperback Publishers Limited.Ọlátúnjí, O. O. 1984. *Features of Yorùbá Oral Poetry*. University Press Plc., Ìbàdàn

Ọ̀pẹ̀féyítìmí, A. 2012. *Ìtúpalẹ̀ Àyájọ́* Ilé Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press.

Rájí, S. M. 1991. *Ìjìnlẹ̀ Ọfọ̀,Ògèdè àti Àásán*, Oníbọnòjé Press Ìbàdàn.

Rájí, S. M, Òjó, I. F., Fátọ́ba S. A. 2009. Àjùwọ̀n, S. A., Fséhùn, M. A. *Ewí Àwíṣẹ Yorùbá: Ọfọ̀*, Alafas Nigeria Co.,Ìbàdàn.

Rájí, S. M, Òjó, I. F., Fátọ́ba Ọlọ́runmọwájú, J. B., Akongwale, E. O. 2009. *Ewí Àwíṣẹ Yorùbá: Ayájọ́ I*,Alafas Nigeria Co.,Ìbàdàn.

# ÌPÍN 2 ÀRÁNGBỌ́ KÉÉKÈÈKÉ

## AKÓÓNÚ


1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Afojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    4.1 Àlọ́ Àpamọ̀
        4.1.1 Bátànì Ìpèdè Inú Àlọ́
            4.1.1.1 Ìpèdè Àsọgbà Inú Ìṣíde Àlọ́ Àpamọ̀
            4.1.1.2 Ìpèdè Ìbéèrè àti Ìdáhùn Àlọ́ Àpamọ̀
        4.1.2 Àfiwé Ẹlẹ́lọ̀ọ́ tó Jinlẹ̀
        4.1.3 Ìwúlò Àlọ́ Àpamọ̀
    4.2 Àrọ̀
        4.2.1 Àbùdá àrọ̀
    4.3 Òwe
        4.3.1 Iṣẹ́ Ìtọ́nisọ́nà
        4.3.2 Àbùdá Aláwẹ́ Méjì
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Ìṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Bí a ti yán an ninú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kìn-ín-ní nínú módù yìí, ìdí méjì ni a fi pe ọ̀wọ́ àwọn ewì alohùn tí a ó gbé yẹ̀wò báyìí ni àrángbọ́ kéékèké. Àkọ́kọ́ ni pé akóónú tàbí ọ̀rọ̀ inú méjì nínú wọn (òwe àti àlọ̀) máa ń mọ níba (tàbí kéré), kì í pọ̀ púpọ̀. Ìdí kejì ni pé ọmọdé kéékèké ni ojúlówó aṣàmúlò méjì nínú wọn (àlọ́ àpamọ̀ àti àrọ̀).

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI AFOJÚSÙN

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó ti lè ṣe àlàyé irúfẹ́ ewì alohùn tí àlọ́ àpamọ̀, àrọ̀ àti òwe jẹ́. O ó tún ti lè ṣàlàyé àwọn tó ń ṣe àmúlò wọn, àkókò tí à ń lò wọ́n àti bí a ṣe ń ṣe àgbékalẹ̀ wọn. O ó ti lè ṣe àlàyé àwọn àbùdá àdání bí i mélòó kantí o fi lè ṣe ìdámọ̀ ìkọ̀ọ̀kan wọn. Bákan náà, o ó lè sọ ìwúlò àwọn ewì àrángbọ náà láwùjọ.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ewì àrángbọ́ kéékèèké mélòó ni ó mọ̀? Dárúkọ wọn, sì sọ ìdí tí wọ́n fi jẹ́ kéékèèké.
2. Ṣe àlàyé nípa àwọn aṣàmúlò àlọ́, àrọ̀ àti òwe Yorùbá.
3. Àbúdá wo ni ó mú àrọ̀ yàtọ̀ sí àwọn ewì àrángbọ́ kéékèèké yòókù? Ṣàlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ tí ó bójú mu.

# 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1.0 Àlọ́ àpamọ̀

Àlọ́ àpamọ̀ ni àwọn ìbéèrè kéékèké nípa àwọn ohun àyíká láwùjọ, èyí tí a gbé kalẹ̀ pẹ̀lú àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tó jinnú, tí olùbéèrè fẹ́ kí àwọn ọmọdé já tàbí dáhùn. Nípasẹ̀ ìrònú jinlẹ̀ àti nípa fífi àbùdá tí a fi gbé àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ kalẹ̀ wé àbùdá àwọn ohun àyíká rẹ̀ ni ọmọdé tí ó fẹ́ já àlọ́ fi lè ṣe àṣeyọrí.Bí Agbájé (2013) tilẹ̀ ṣàlàyé, ìtumọ̀ àlọ́fara sin, ṣùgbọ́n síbẹ̀ a lérò pé bí a bá wo àlọ́ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ orúkọ ìṣẹ̀dá, a óò rí ojútùú sí ìtumọ̀ rẹ̀ tí ó dà bí ẹni fara sin náà. Ọ̀rọ̀ ìṣe 'lọ́' tí ó lè túmọ̀ sí yálà kí ènìyàn lọ́ nǹkan pọ̀ wérékéké,kí ènìyàn di ohun kan pamọ́ tàbí kí èèyàn gbin àwọn oríṣi ohun ọ̀gbìn kan ni ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀ nínú ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ náà. Òun ni à sọ àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀/à-/ mọ́ tí ó sì di àlọ́. (à- + lọ́ > àlọ́). Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀ a jẹ́ pé èyí/ohun tí a lọ́ ni àlọ́ túmọ̀ sí. Ohun tí èyí ń pe àkíyèsí sí ni àdìtú tí apalọ́ lọ́, tàbí tí ó dì pamọ́ sínú àlọ́. (Wo Ogundèjì 1991 náà fún irú àlàyé yìí). Àdìtú yìí ni ni ọmọdé tí ó jẹ́ olùgbọ́ àlọ́ níláti wá ìtumọ̀ sí nínú èsì tí yóò fi dáhùn nígbà àlọ́ pípa. Ìdí sì nìyí tí wọ́n fi pè é ní àpamọ̀. Èyí ni wí pé àla ti a níláti mọ ìtumọ̀ rẹ̀, kí á sì sọ ọ́.

Lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́, nígbà tí ọjọ́ bá tí bora, tí ilẹ̀ sì ṣú ni àsìkò àlọ́ pípa ní ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́. Ìdí ni pé àwọn Yorùbá gbà olóòrayè níí pàlọ́ ní ọ̀sán. Wọ́n ka ẹni tó bá tẹ́ pẹpẹ àlọ́ pípa lọ́sàn-án sí ọ̀lẹ, afàjò, aláìníkanán-ṣe.Ṣùgbọ́n ìyípadà tí bá ojú ìwòye yìí nítorí ọ̀làjú lóde òní. Àlọ́ pípa a máa wáyé ní orí rédíò àti tẹlifíṣàn lójú-mọmọ. Àlọ́ pípa lè wáyé ní ilé ẹ̀kọ́ bágbàmu tàbí láàrin àwọn ọmọdé ní ọ̀sán ní òde òní. Àlọ́ àpamọ̀ ni a máa ń fi ṣe ìfáárà sí àlọ́ onítàn (àlọ́ àpagbè) pípa, ìyẹn ni pé òun ni a kọ́kọ́ máa ń pa ṣaájú àlọ́ onítàn. Àgbàlagbà ni ó máa ń sábàá pa àlọ́ fún àwọn ọmọdé. Àgbàlagbà yìí le jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin ṣùgbọ́n inú irúfẹ́ àgbàlagbà bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ gba àwàdà, ó sì gbọ́dọ̀ le jẹ́ onísùúrù, tí ó kó ọmọdé mọ́ra. Nígbà tí àsìkò láti pa àlọ́ bá tó, àwọn ọmọdé yóò kóra jọ sí gbàgede ilé tàbí ọ̀dẹ̀dẹ̀ baba/ìyá aláàlọ̀ọ́ láti gbọ́ àlọ́. Lẹ́yìn tí baba/ìyá aláàlọ̀ọ́ bá ti kí àwọn ọmọ náà kú àbọ̀ tán, nígbà mìíràn, ó le béèrè ẹ̀kọ́ tí wọ́n rí kọ́ nínú àlọ́ tí wọ́n pa ní ọjọ́ tó ṣíwájú ọjọ́ náà, bí àkókò kò bá sí láti ṣe ìwọ̀nyí, àlọ́ àpamọ̀ ni apàlọ́ yóó fi fáàrà/ṣíde àlọ́ gbígbọ́ náà láì fi àkókò ṣòfò. Ẹ jẹ́ kí á wo bátànì gbólóhùn àlọ́ àpamọ̀. Àwọn ohun tí a jíròrò lé lórí báyìí ni àbùdá àlọ́ méji tí ó jẹ mọ́ ìhun àti ìgbékalẹ̀ àlọ́ pẹ̀lú ìwúlò tàbí àǹfàní àlọ́.

### 4.1.1 Bátànì Ìpèdè Inú Àlọ́ Àpamọ̀

Ìlànà Àsọgbà tàbí ìsọ̀rọ̀ǹfèsì ni a fi máa ń ṣe ìgbékalẹ̀ àlọ́ àpamọ̀. Àpàlọ́ ni yóò kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ kí àwọn agbálọ̀ọ́, ìyẹn àwọn ọmọdé tí wọ́n jẹ́ olùgbọ́, tó dáhùn sí i. Ọ̀nà méjì ni bátànì ìpèdè àsọgbà náà pín sí; ti àkọ́kọ́ jẹ́ ìsọ̀rọ̀ǹfèsì ìṣíde àlọ́ àpamọ̀, tìkejì sì jẹ́ tiàlọ́ àpamọ̀ náà gan-gan.

### 4.1.1.1Ìpèdè ÀsọgbàInú Ìṣíde Àlọ́ Àpamọ̀

Bí apàlọ́ bá ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀àlọ́, yóò kọ́kọ́ sọ pé "Ààlọ́ ooo!". Ìtumọ̀ tí a lè fún ìpèdè yìí bí apàlọ́ ṣe lò ó ní ọ̀gangan ipò yẹn ni wí pé àlọ́ pípa ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀. Ohun tí ìpèdè náà ń retí ni èsì wí pé àwọn ti ṣe tán, àwọn sì wà ní ìmúrasílẹ̀ láti gbọ́ àlọ́ náà. Láìsí àní àní apàlọ́ ń fi ìpèdè náà ké sí àwọn àgbálọ̀ọ́ ni.Ìpèdè tí àwọn agbálọ̀ọ́ náà yóò sì fi fèsì ni "Ààlọ̀!" Ìfàgùn fáwẹ́lì ìbẹ̀rẹ̀ ìpèdè apàlọ́ àti agbálọ̀ọ́ bara mu, ṣùgbọ́n ohùn tí ó parí rẹ̀ yàtọ̀ síra. Ohùn òkè tí ó wà nínú ọ̀rọ̀ náà tẹ̀lẹ̀ ni apàlọ̀ọ́ lò, nígbà tí agbálọ̀ọ́ lo ohùn ìsàlẹ̀ ní tirẹ̀. Ìyàtọ̀ inú ohùn yìí ni a lérò pé ó ń tọ́ka sí i wí pé apàlọ̀ọ́ ń ṣe ìkésíni ni àti wí pé àwọn agbálọ̀ọ́ náà ti wà ní ìmúrasílẹ̀, wọ́n ti ṣe tán láti gbọ́ àlọ́ náà. Wúnrẹ̀n ìtẹnu mọ́rọ̀ "...ooo" tí apàlọ́ lò tún fi òté lé àkíyèsí tí a ṣe yìí, nítorí pé bí a ṣe máa ń lò ó tí abá ńké síni náà nìyẹn ní ojoojúmọ́.Ohùn ìsàlẹ̀ tí agbálọ̀ọ́ lò tún ń tọ́ka sí ìfaramọ́ àti ìlọ́wọ́sí ìgbékalẹ̀ àlọ́ náà. Ìyẹn ni pé gbogbo àwọn agbálọ̀ọ́ gbà láti tẹ̀lé àwọn ìlànà tó rọ̀ mọ́ àlọ́ pípa,nípa ríronú jínlẹ̀ àti dídáhùn ìbéèrè tí apàlọ́ yóò bi wọ́n. Bí wọn bá sì fi ẹ̀gbin lọ̀ wọ́n nígbà tí wọn kò bá gba ìdáhùn sí ìbéèrè kan, wọn yóò fi ṣosùn, wọn yóò fi para ni, wọn kò gbọdọ̀bínú.

### 4.1.1.2Ìpèdè Ìbéèrè Àti Ìdáhùn Àlọ́ Àpamọ̀

Bátànì ìbéèrè àti ìdáhùn ni wọ́n fi ń ṣàgbékalẹ̀ àlọ́ àpamọ̀. Apàlọ́ ní í máa béèrè ìbéèrè, tí agbálọ̀ọ́ yóò sì máa dáhùn. Ọ̀nà méjì ni a le fi ṣe àgbékalẹ̀ ìbéèrè àlọ́. Àkọ́kọ́ ni lílo atọ́ka ìbéèrè (#Kín ni ....#), ìkejì sì ni àìlo atọ́ka ìbéèrè,.Ní ti ọ̀nà kejì yí apàlọ́ yóò kàn gbé àditú náà kalẹ̀ fún agbálọ̀ọ́ láti já ìtumọ̀ rẹ̀ ni. Àpẹẹrẹ:

1. Kín ni ń bọ́ba mutí o?
2. Kín ni ń kọjá lẹ́kùlé ọba tí kì í kọ́ba o?
3. Kín ni èsìsì abẹ́ ìró/kò<br>A-jó-ni má ṣe é já o? (Agbájé, 2013: 89)
4. Òrúkú tindítindí<br>Òrúkú tindì tindì<br>Òrúkú bígba ọmọ, gbogbo wọn ló lé tiróò o.<br>Kín ni o?
5. Ìkòkò dúdú tìdí bọ̀gbẹ́, kín ni?
6. Gbogbo ilé yìí kìkì ìyere o.
7. Lọ́jọ́ tó bá ti bá ènìyàn dáyé ló ń pínyà pẹ̀lú ẹni o.
8. Òkúta rùbúrùbú ẹ̀yìnkùlé àjẹ́.
9. Òkúta wẹ́wẹ́ òkè ẹ̀sún. (Fún 6, 7, 8, 9:Adésúà, 1978: 19, 24)
10. Apọ́nmádèénú,<br>Aràmátàdin,<br>Àgbà kan tilé tẹ̀pá rọjà.<br>Mẹ́ta là á pa á sí,<br>Mẹ́ta là á mọ̀ ọ́n.

Ọmọ láyílo
11. Bámigbélé kì i yáná,
Abọ̀rìṣà kì í sun òtútù,
Ẹyingẹdẹ kì í fara kanni.
Mẹ́ta là á pa á,
Mẹ́ta là á mọ̀ ọ́n. (Agbájé, 2013: 82)

Kíyèsí i pé a lo atọ́ka ìbéàrè “Kín ni?” fún àpẹẹrẹ 1 dé 5, nígbà tí a kò lò ó fún àpẹẹrẹ 6 dé 11. Bí apàlọ́ ti ń pa àlọ́ ni àwọn ọmọ náà yóò máa dá a lóhùn tí wọn ó máa já àlọ́ náà. Tí wọn bá gbà a yóò gbé oríyìn fún wọn, ṣùgbọn èyí tí kò bá sí ẹnìkankan tí ó lè já a ni yóò lo àwọn ìpèdè ìsàlẹ̀ wọ̀nyí láti já àlọ́ náà fún wọn. Kí a sọ pé àlọ́ 1 ni ọmọ kankan kò lè já àpẹẹrẹ bí apàlọ́ yóò ṣe já a fún wọn nìyí:

Àpàlọ́: Ẹ sọ pé kùn-ún-ùn!
Agbálọ̀ọ́: Kùn-ún-ùn!
Apàlọ́: Mo fi rẹ́ tojútimú yín ọ̀bẹ́rẹ́kẹ́tẹ́ o!
Agbálọ̀ọ́: A fara mọ́ ọn!
Apàlọ́: Eṣinṣin ni o!

A lérò pé ọgbọ́n ìgbétumọ̀ àlọ́ tuntun tí àwọn ọmọ kò gbọ́ rí, tí wọn kò sì mọ ìtumọ̀ rẹ̀ kalẹ̀ báyìí ni kò ní í jẹ́ kí wọ́n máa tètè gbàgbé.

Lẹ́yìn tí apàlọ́ bá ti já àlọ́ tí àwọn ọmọdé tí wọ́n jẹ́ agbálọ̀ọ́ tán àwọn agbálọ̀ọ́, ó ṣe é ṣe kí á rí ọmọ tí yóó béèrè ìdí ìtumọ̀ àlọ́ náà fi jẹ́ ohun tí apàlọ́ pè é yẹn. Apàlọ́ yóò sì ṣàlàyé fún wọn ní kíkún. Ní kété tí apàlọ́ bá ti pa àlọ́ bíi mélòó kan, yóó bẹ̀rẹ̀ sí pa àlọ́ onítàn fún àwọn ọmọ. Ìdáhùn tí ó tọ̀nà sí àwọn àlọ́ mọ́kọ̀ọ̀kànlá inú àpẹẹrẹ wa nìwọ̀nyí: 1) Eṣinṣin, 2) Àgbàrá òjò,3) Ebi,4) Erèé (ẹ̀wà tútù),5) Ìgbín,6)Imí ẹran,7) Olubi ọmọ, 8) Ẹyin adìẹ, 9)Ìràwọ̀ojú ọ̀run, 10) Ẹyìn ọ̀pẹ, Ọṣẹ dúdú àti Òkété, 11) Ẹ̀tù ìbọn, aró àti wèrèpè.

### 4.1.2 Àfiwé Ẹlẹ́lọ̀ọ́ Tó Jinlẹ̀

Yàtọ̀ sí bátànì ìpèdè ìgbálọ̀ọ́-kalẹ̀ tí a ti ṣàpèjúwe yìí, àbùdá pàtàkì kan tó tún ya àlọ́ sọ́tọ̀ ni àmúlò àfiwe ẹlẹ́lọ̀ọ́ tó jinnú. Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tó jinlẹ̀ gan-anni apàlọ́ máa ń fi ṣàgbékalẹ̀ ìbéèrè àlọ́. Nípasẹ̀ àmúlò àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tó jinlẹ̀ gan-an ní apàlọ̀ fi máa ń sọ nǹkan tí èniyàn mọ̀ dáadáa tẹ́lẹ̀ di àjèjìsíni tàbí di ohun ti ènìyàn kò wá fẹ́ da mọ̀ mọ́. Èyí ni ó sì mú kí àfiwé náà jinú tàbí kí ó jinlẹ̀ gan-an bí ati sọ. Kí á tó lè fi ohun méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ wé ara wọn, wọ́n níláti ní ohun kan, ó kéré tán tí wọ́n fi jọra. Ibi ìjọra yìí ni ó máa farasin tí ó sì máa ń jẹ́ kí àfiwé náà dàbí ohun tí ó ṣàjẹ̀jì síni bí a ṣe sọ. Láti le já àlọ́ tí a bá pa, tàbí láti le mọ ohun tí àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tí a gbé kalẹ̀ ń tọ́ka sí, agbálọ̀ọ́ níláti kíyèsí àbúdá tí a tẹnu mọ́ nínú àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tí a gbé kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àlọ́, kí ó sì wo ìṣesí ohun tí ó le fi

èyí wé ní àwùjọ. Èyí yóò ràn án lọ́wọ́ láti mọ̀ ìtumọ̀ àlọ́ tí a pa tàbí kí ó sọ ohun tí ó sún mọ́ ìtumọ̀ àlọ́ náà. Ó yẹ kí á tún rán ara wa létí wí pé ohun tí a mọ̀-ọ́n-mọ̀ lọ́ pọ̀, kí ó lè rúni lójú ni àlọ́.

Ẹ jẹ́ kí á ṣe ìtúpalẹ̀ àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ inú àpẹẹrẹ 1 dé 4 tí aṣe sókè láti wa àlàyé wa gúnlẹ̀ dádáa.Nínú àpẹẹrẹ1 àti 2 a ti ta wá ní olobó pé ènìyàn kọ́ ni ìdáhùn àwọn àlọ́ náà nítorí wúnrẹ̀n aṣebéèrè "Kín ni" tí a lò. Ṣùgbọ́n bí a bá wo ìyókù àgbékalẹ̀ náà a óò rí i wí pé ohun tí kì í ṣe ènìyàn yìí ni a fi ń wé ènìyàn. Nínú àpẹẹrẹ 1 ohun náà a máa bá ọba mutí. Nínú àpẹẹrẹ2 ohun náà kìí bìkítà láti kí ọba bí ó bá gba ẹ̀kúlé (tàbí ojúde – bí àwọn mìíràn ṣe máa ń pa àlọ́ náà) ọba kọjá. Ohun tí ó mú kí àfiwé inú àwọn àlọ́ náà ṣàjèjì ni pé ènìyàn àti ohun tí kì í ṣe ènìyàn ni a fi ń wéra àti pé àwọn ìwà tí a ṣàpèjúwe pé ohun náà hù kó bá ojúwoye ọmọlúwàbí inú àṣà àbínibí Yorùbá mu. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú eṣinṣin ni ìdáhùn sí àlọ́ 1, àgbàrá sì ni ti 2, wọn kì í ṣènìyàn. Ẹṣinṣin lè bà setí igbá tí ọba fi ń mu ọtí kí ó sì tẹnu bọ ọtí náà, bákan náà ni pé ojú ipa àgbàrá ni àgbàrá máa ń tọ̀ kọjá lẹ́yìnkùlé tàbí ojúde ọba. Tí àgbàrá bá ré ipa rẹ̀ kọja, tí ó ya wọ àfin ọba, kì í ṣe pé ó lọ kí ọba rárá, omiyalé ni ó dà yẹn, yóò ba nǹkan jẹ́, inú ọba àti àwọn ènìyàn rẹ̀ kò sì lè dùn sí i. Gbogbo ìwọ̀nyí ni ète ìsọdàjèjì, tí ó gba ìrònú jinlẹ̀ kí ọmọ tó lè jánà rẹ̀, bí kò bá gbọ́ ọ rí tẹ́lẹ̀.

Nínú àpẹẹrẹ kẹta ebi ni a fi wé èsìsì abẹ́ ìrókò. Tí èsìsì, (oríṣi èèmọ́ kan tí í máa jónìyàn lára) ba jó ènìyàn ní abẹ́ igi ìrokò, tàbí igikígi, kíá ni èèyàn ó fọwọ́ já a dànù, nítorí ìnirajíjó tí ó jóni. Bí ebi bá ń pani tí a sì ń ní ìnira nípasẹ̀ rẹ̀ kò sí bí a ṣe lè fọwọ́ já a bí ìgbà tí èèyàn já èsìsì kúrò lára, àyàfi kí ènìyàn jẹun. Fífúnni ní ìnira yẹn ní èsìsì abẹ́ ìrókò àti ebi fi jọra. Àìṣe é fọwọ́ já ebi jẹ́ ohun pàtàkì tí a fi sọ àfiwé náà di àjèjì síni. Abẹ́ ìrókò tí a tún ki èsìèsi mọ́ nínú àlọ́ náà tún wà lára ohun tí a lè sọ pé a fi sọ ọ́ dàjẹ̀jì síwájú sí i. Bí i ti àwọn àpẹẹrẹ méjì àkọ́kọ́ erèé (ẹ̀wà tí a kò tí ì sè), tí kì í ṣe ènìyàn ni a fi ń wé ọmọ bíbí ẹ̀dá ìtàn kan tí ń jẹ́ Òrúkú nínú àpẹẹrẹ kẹrin. Èyí ni ète ìsọdàjèjì ibẹ̀. Ọlọ́mọ bẹẹrẹ ni Òrúkú gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé erèé tí a máa ń rí láti inú ẹyọ hóró erèé kan ṣoṣotí a gbìn máa ń pọ̀. Ojú erèé tí ó sì máa ń dúdú ni a fi wé tìróò ti a sọ pé àwọn ọmo Ọrúkú lé.Ọ̀nà méjì ìgbẹ̀yìn yìí ni wọ́n fi jọra. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ àwọn ọ̀nà ìsọdàjèjì wọ̀nyí ni ó máa gba ìronú jinlẹ̀ dáradára ki ọmọ tó lè mọ ìtumọ̀ àlọ́. idí sì ni èyí tí a fi rí àwọn àfiwé náà bí èyi ti ó jìnlẹ̀ tàbí tí ó lọ́jú.

### 4.1.3 Ìwúlò Àlọ́ Àpamọ̀

Ìwúlò àlọ́ àpamọ̀ pọ̀. Ó ń ta àwọn ọmọdé jí láti máa kíyèsí àwọn ohun àyíká wọn. Ó ń ran àròjinlẹ̀ ọmọdé lọ́wọ́. Ó ń ran ọmọdé lọ́wọ́ láti fa òye yọ nínú àkíyèsí wọn. Ó ń jẹ́ kí ọmọdé gbà pé ìrírí àwọn àgbàlagbà pọ̀ ju tiwọn lọ́, àti wí pé, ó yẹ kí àwọn máa kíyèsí ọ̀rọ̀ àgbà. Àlọ́ àpamọ̀ tún ń kọ́ ọmọdé láti mọ bí a ṣe ń dá sí ọ̀rọ̀ láwùjọ. Ó ń kọ́ ọmọdé ní àwọn èdè tuntun tí kò gbọ́ rí.Ọ̀nà ìdánilárayá pàtàkì kan sì ni àlọ́ àpamọ̀ jẹ́. Lótìítọ́

irọ̀ ni Yorùbá ń pè ní àlọ́ ṣùgbọ́n àlọ́ a máa fìdí àwọn òdodo kan nípa ayé múlẹ̀ lọ́kàn àwọn ọmọdé, wọn yóò sì máa ṣe àmúlò àwọn òdodo wọ̀nyí ní gbogbo ìgbèésí ayé wọn. Bí a bá wo àpẹẹrẹ àlọ́ yìí, "Igbó tó gberin, to gbẹfọ̀n, kò gba ọmọ Àjàǹtálá, ọmọ Àjàǹtálá kò sì tó èèrà." Ìdáhùn àlọ́ náà ni ìṣáná tàbí ògúnná. Lótìítọ́, ìṣáná kò tóbi bí erin tàbí bí ẹfọ̀n, ṣùgbọ́n bí ìṣàná tí a ti ṣá bá kań lu inú igbó ńlá tí àwọn ẹranko ńláńlá wà, igbó náà kò níí gba ìṣáná ní àkókò púpọ̀láti jó o tán, tí yóò sì tún fi kọjá sínú igbó mìírán tó wà ní ìtòsí, tí gbogbo ẹran ibẹ̀ yóò sì sá àsálà fún ẹ̀mí wọn tàbí kí wọ́n kú tí ọwọ́jà iná bá bà wọ́n. Torí náà, àlọ́ yìí fi múlẹ̀ lọ́kan ọmọdé pé lótìítọ́ ni ìṣáná tàbí ògúnná le kéré, síbẹ̀ ó le ṣọṣẹ́ tí ohun tó tobí jù ú lọ kò le ṣe. Yàtọ̀ sí ìwúlò wọ̀nyí tí ó jẹmọ́ ìkọ́mọ lẹ́kọ̀ọ́ ní ìgbáradì fún ìgbésí ayé rẹ̀ lọ́jọ́ iwájú, àlọ́ àpamọ̀ tún dúrúo gẹ́gẹ́ bí ìtọ́wò àti ìpalẹ̀ ọkàn àwọn olùgbọ́ mọ́ sílẹ̀ fún àlọ́ onítàn tí wọn yóò gbọ́ lẹ́yìnọ̀rẹyìn.

## 4.2.0 Àrọ̀

Àrọ̀ kò fi bẹ́ẹ̀ gbajúmọ̀ gẹ́gẹ́ bí òwe àti àlọ́ àpamọ̀. Àwọn Ìjẹ̀ṣà a máa pe àrọ̀ ní "ìmọ̀", àwọn Ẹ̀gbá a sì máa pè é ní "pẹ́rọ̀ọ̀." Àrọ̀ ni ẹ̀yà ewì alohùn kan tí ìhun àwọn gbólóhùn inú rẹ̀ máa ń rọ̀ mọ́ ara wọn tàbí tí ó máa ń kọ́ra wọn bí ẹ̀wọ̀n. Àrọ̀ (à + rọ̀) túmọ̀ sí ohun tí ó rọ̀ mọ́ ara wọn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀wọ̀n ṣe rọ̀ mọ́ ara wọn. Torí pé àwọn àrọ kan máa ń jẹyọ nínú ẹsẹ ifá ni a ṣe ní lérò pé ẹsẹ ifá ni orísun àrọ̀. Rájí (2002) tilẹ̀ sọ pé, àwọn ẹsẹ ifá kan tí babalawo kì fún àwọn ọ̀gbẹ̀rì ṣùgbọ́n tí àwọn ọ̀gbẹ̀rì náà tún tún kì fúnra wọn bí ó ṣe yé wọn mọ ni àlọ́ àti àrọ̀. Bóyá èyí ló fa bí àlọ́ onítàn ṣe máa ń yí wọ inú àrọ̀. Jíjá ni wọ́n máa ń já àrọ̀. Ènìyàn kan ṣoṣo le já àrọ̀.Ẹni méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ sì lé já a. Èyí máa ń wáyé nínú àrọ̀ tó ní bátànì ìbéèrè àti ìdáhùn. Àwọn àrọ̀ kan wà tó jẹ́ pé bí àlọ́ onítàn ni a ṣe máa ń já wọn 'ti ó jẹ́ pé ọ̀rọ̀ wuuru ni a fi máa ńgbé púpọ̀ rẹ̀ kalẹ̀. A kò níí sọ̀rọ̀ lórí irúfẹ́ àrọ̀ yìí ní ibí torí pé ó jẹ mọ́ ìtàn àròsọ alòhùn gẹ́gẹ́ bí Ògúnpòlù (1986) ṣe fi í hàn. Àrọ̀ ajẹmẹ́wì ni ó kàn wá nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Àrọ̀ tí àwọn ọmọdé máa ń já ni ó kàn wá ní ìhín. Àwọn àrọ̀ kan kì í gùn púpọ̀ ṣùgbọ́n àwọn kan a máa gùn dáradára. A le já àrọ̀ tó jẹ mọ́ erémọdé ní ojúmọmọ, a sì le já a nínú eré òṣùpá. Torí pé ewì alohùn ní à ń jíròrò lé lórí, àrọ̀ ajẹmẹ́wì ni a máa ṣàgbéyẹ̀wò bí a ti sọ.Àpẹẹrẹ àrọ̀ ajẹmẹ́wì ni "Lúbúlúbú ta ni ó rọjà bó bá dalẹ̀", "Ǹjẹ́ o búmọ̀-ọ̀n" àti "Jọ́ńpẹ jọ́ǹpẹ".

Gẹ́gẹ́ bí àlọ́ apamọ̀, àrọ̀ a máa kọ́ àwọn ọmọdé ní ẹ̀kọ́ ọ̀rọ̀ sísọ ní àwùjọ. Òhun náà máa ń pe àkíyèsí àwọn ọmọdé sí àwọn ohun àwùjọ wọn. Àrọ̀ jẹ́ ọ̀nà láti jẹ́ kí àwọn ọmọdé ṣeré papọ̀, èyí yóò sì jẹ́ kí wọn le jìjọ máa fi ìfẹ́ gbé papọ̀. Àwọn ọmọdé máa ń lo ẹ̀kọ́ tí wọ́n bá rí kọ́ nínú àrọ̀ láti yanjú àwọn ìpèníjà ojoojúmọ́ tí ń máa ń kojú ẹ̀dá ní àwùjọ.

### 4.2.1 Àbùdá àrọ̀

Àbùdá kan ṣoṣo tó gbajúgbajà nínú àrọ̀ ajẹmẹ́wì ni àbùdá ajẹmọ́hun inú rẹ̀ tí ọ̀rọ̀ inú rẹ̀ máa ń rọ̀mọ́ ara wọn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀wọ̀n ṣe máa ń rọ̀ mọ́ra gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣàlàyé tẹ́lẹ̀. Èyí já sí pé ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ọ̀rọ̀ tí ó bá parí gbólóhùn àkọ́kọ́ ni gbólóhùn kejì yóò fi bẹ̀rẹ̀, èyí tí ó b’’a parí ìkejì ni ìkẹta yóò sì fi bẹ̀rẹ̀ àati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ní ìgbà míràn ẹ̀wẹ̀, ọ̀rọ̀ tí ó parí gbólóhùn àkọ́kọ́ lè wà láàrin gbólóhùn kejì kí tí ìkejì wà láàri tí ìkẹta àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lọ́rọ̀ kan ọ̀rọ̀ kan pàtàkì nínú gbólóhùn àkọ́kọ́ yóò fara hàn nínú èkejì, kí tí ìkejì fara hàn nínú ìkẹta àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bátànì ìkọ́ra tàbí ìrọ̀mọ́ra yìí yóò wá sú yọ nínú èyí tí ó pọ̀ jù nínú ìhun ewì náà tàbí kí ó tilẹ̀ la gbogbo rẹ̀ já. Èyí ni a lérò pé ó fa orúkọ ewì alohùn yìí, àrọ̀. Àpẹẹrẹ nìwọ̀nyí:

1. Lílé: Lúbúlúbú táni ó rọjà alẹ́
Ègbè: Èmi ó lọ.
Lílé: Bá mi rayọ̀ olóókan bọ̀.
Ègbè: N ò lọ mọ́.
Lílé: Kíló wá dé?
Ègbè: Kò sí ǹǹkan kan.
Lílé: Ǹjẹ́ o bú ìmọ́?
Ègbè: Mo bú ìmọ́.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ ìmọ́?
Ègbè: Ìmọ́ ládé.
Lílé: Kín ní ń jádé?
Ègbè: Adéṣípò.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ ipò?
Ègbè: Ipò ǹṣẹ́rẹ́.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ ìṣẹ́rẹ́?
Ègbè: Ìṣẹ́rẹ́ Ọmọ́yọ.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ Ọmọ́yọ?
Ègbè: Ọmọ́yọ àkókó.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ àkókó?
Ègbè: Àkókó òrìṣà.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ òrìṣà?
Ègbè: Òrìṣà alayé.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ alayé?
Ègbè: Alayé alọ̀run.
Lílé: Kín ní jẹ́ alọ̀run?
Ègbè: Alọ̀run ekòló.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ ekòló?
Ègbè: Ekòló ajúbà.
Lílé: Kín ní jẹ́ ajúbà?
Ègbè: Ajúbà arẹrẹ.
Lílé: Kín ní jẹ́arẹrẹ?
Ègbè: Arẹrẹ́ńmògún.
Lílé: Kín ní jẹ́ mògún?

Ègbè: Mògún onírè.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ onírè?
Ègbè: Onírè afọn.
Lílé: Kín ní jẹ́ afọn?
Ègbè: Afọn oníyẹ̀ẹ́.
Lílé: Kín ní jẹ́ ìyẹ́?
Ègbè: Ìyẹ́ àṣá.
Lílé: Kín ní jẹ́ àṣá?
Ègbè: Àṣá òkè.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ òkè?
Ègbè: Òkè ilẹ̀.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ ilẹ̀?
Ègbè: Ilẹ̀ òwú.
Lílé: Kín ní ń jẹ́ Owú?
Ègbè: Òwú aṣọ.
Lílé Kín ní ń jẹ́ aṣọ?
Ègbè: Aṣọ n mo ró.
Lílé: Igi lo ró.
Ègbè: Aṣọ n mo ró....

2. Lílé: Jọ́ńpẹ jọ̀ǹpẹ o
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: Ẹ wá wọmọ yìí o
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: Tó wá ṣu imí yìí o
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: A pọmọ
Ọmọ ọmọ kọ̀
Ọmọ kò ṣumí ire
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: Ẹ bá mi pajá yìí o
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: Kó wá jẹmí yìí o
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: A pajá
Ajá ajá kọ̀
Ajá kò jẹ́mí ọmọ
Ọmọ ọmọ kọ̀
Ọmọ kò ṣumí ire
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: Jọ́ńpẹ jọ̀ǹpẹ o
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: Ẹ bá mi pegí yìí o
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: Kó wá najá yìí o
Ègbè: Jọ́ńpẹ

Lílé: A pegi
Igi igí kọ̀
Igi kò nàjá
Ajá ajá kọ̀
Ajá kò jẹmí ọmọ
Ọmọ ọmọ kọ̀
Ọmọ kò ṣumí ire
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: Jọ́ǹpẹ jọ̀ǹpẹ ò
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: Ẹ bámi pená yìí ò
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: Kó wá jógi yìí ò
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: A pená
Iná iná kọ̀
Iná kò jógi
Igi igi kọ̀
Igi kò najá
Ajá ajá kọ́
Ajá kò jẹmí ọmọ
Ọmọ ọmọ kọ̀
Ọmọ kò ṣumí ire
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: Jọ́ǹpẹ jọ̀ǹpẹ ò
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: Ẹ bámi pomi yìí ò
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: Kó wá paná yìí ò
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: A pomi
Omi omí kọ̀
Omi kò paná
Iná iná kọ́
Iná kò jógi
Igi igi kọ̀
Igi kò najá
Ajá ajá kọ̀
Ajá kò jẹmí ọmọ
Ọmọ ọmọ kọ̀
Ọmọ kò ṣumí ire
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: Jọ́ǹpẹ jọ̀ǹpẹ ò
Ègbè: Jọ́ǹpẹ
Lílé: Ẹ bámi pòrùn yìí ò
Ègbè: Jọ́ǹpẹ

Lílé: Kó wá lámi yìí ò
Ègbè: Jọ́ńpẹ
Lílé: A pòrùn
Òrùn òrùn kọ̀
Òrùn kò lámi
Omi omí kọ̀
Omi kò paná
Iná iná kọ́
Iná kò jógi
Igi igi kọ̀
Igi kò najá
Ajá ajá kọ́
Ajá kò jẹmí ọmọ
Ọmọ ọmọ kọ̀
Ọmọ kò ṣumí ire
Ègbè: Jọ́ńpẹ

Àpẹẹrẹ kìn-ín-ní jẹ́ àrọ̀ oníbéèrè àtìdáhùn. Bí aṣe sọ, èyí ń tọ́ka sí i pé èniyàn méjì ni yóò jìjọ ṣe é, tí wọn óò máa sọ ọ́ ní àsọgbà. Ìfáárà ni ìlà mẹ́fà àkọ́kọ́ jẹ́ sí àgbékalẹ̀ àrọ̀ náà gangan. Níbẹ̀ sì ni ìbéèrè àtìdáhùn ti bẹ̀rẹ̀. Inú ìlà keje ni bátànì ìhun àrọ̀ ti bẹ̀rẹ̀. Níbẹ̀rẹ̀ àrọ̀ yìí gan-an, “ìmọ́” ni ọ̀rọ̀ tí ó kọ́ra wọn nínú ìlà mẹ́rin àkọ́kọ́. Ìparí ìlà mẹ́ta àkọ́kọ́ nínú mẹ́rin yìí sì ni ọ̀rọ̀ náà ti jẹyọ. Ohun tí ó fa eléyìí ni pé bátànì ìbéèrè kìn-ín-ní ní ìlà àkọ́kọ́ “Ǹjẹ́ o bú ìmọ́?” àti ìdáhùn rẹ̀ “Mo bú ìmọ́” yàtọ̀ sí bátànì tí ó la inú ìyókù ewì náà já. Bátànì #“Kín ní ń jẹ́X ?”# tí ìdáhùn rẹ̀ sì gba # X ni –- # ni ó la ìyókù àrọ̀ náà já.Ohun tí a bá dárúkọ náà ni X dúró fún. Nígbà tí elégbè ti gbà pé òún bú ìmọ́ nínú ìdahùn rẹ̀ sí ìbéèrè àkọ́kọ́ yẹn, ìbéèrè tí ó tẹ̀lé e, tí a sọ pé bátànì tí o la àrọ̀ náà já ni pé“Kín ni ń jẹ́ ìmọ́?” Láti ìhín lọ ni bátànì kí ọ̀rọ̀ tí a fi parí gbólóhùn ìlà ìṣaájú, tí ó jẹ́ ìbéèrè, máa bẹ̀rẹ̀ ìlà tó tẹ̀lé e, tí ó jẹ́ ìdáhùn. Ìdáhùn sí “Kín nibń jẹ́ ìmọ́?” nínú àrọ̀ òkè yìí ni “Ìmọ́ ladé”. Ìbéèrè tí ó kàn tí ó jẹ́ ìkẹta tí ẹni tí ó ń lé àrọ̀ yóò béèrè ni ohun tí adé jẹ́ “Kí ní ń jádé?” elégbè yóò sì dáhùn pé “Adéṣípò.” Bátànì tí ó wá sú yọ ni a lè fí àwòrán gbé jáde báyìí:

[
Lílé: Ǹjẹ́ o bú **ìmọ́**?
Ègbè: Mo bú **ìmọ́**
Lílé: Kín ní ń jẹ́**ìmọ́**?
Ègbè: **Ìmọ́** **ládé**
Lílé: Kín ní ń **jádé**?
Ègbè: **Adéṣípò**
Lílé: Kín ní ń jẹ́ **ipò**?
Ègbè: Ipò **ǹṣẹ́rẹ́**
Lílé: Kín ní ń jẹ́ **ìṣẹ́rẹ́**?
Ègbè: **Ìṣẹ́rẹ́Ọmọ́yọ** ]



Bátànì àsọgbà inú àpẹẹrẹ kejì kì í ṣe toníbéèrè àtìdáhùn olórin alakọgbà papọ̀ mọ́ taládàáko ni. Àwọn orin rẹ̀ ni ó dúró bí okùn tí ó ń so àwọn ẹ̀ka tí ó jẹ́ àrọ̀ pọ̀. Gbogbo ìsọ̀rí orin alákọgbà inú ewì náà jẹ́ mẹ́fà, àwọn ìsọ̀rí àrọ̀ ibẹ̀ sì jẹ́ márùn-ún. Ìsọ̀rí àrọ̀ ibẹ̀ ni ó jẹ́ àdáko ẹni tó ń lé àrọ̀. Nínú àwọn ìsọ̀rí àrọ̀ náà ni àwọn ọ̀rọ̀ ti ń kọ́ra bí ẹ̀wọ̀n wà. Nínú ìsọ̀rí àrọ̀ àkọ́kọ́ ni a ti pe ọmọ kí ó wá ṣumí, ṣùgbọ́n tí ó kọ̀ láti ṣumí ire. Ọmọ ni ọ̀rọ̀ tí ókọra bí a ṣe fi hàn nísàlẹ̀ yìí:

A p**ọmọ**
**Ọmọ** ọmọ kọ̀
**Ọmọ** kò ṣumí ire

Nínú ìsọ̀rí àrọ̀ kejì ni wọ́n ti pe ajá kí ó wa kó imíkímí tí ọmọ ṣu jẹ, ṣùgbọ́n tí òun náà kọ̀. Wọ́n tún wá so ó papọ̀ mọ́ ti ìsọ̀rí àkọ́kọ́ bí a ti fi hàn yìí:

A p**ajá**
**Ajá** ajá kọ̀
**Ajá** kò jẹmí **ọmọ**
**Ọmọ** ọmọ kọ̀
**Ọmọ** kò ṣumí ire

Bí ó ti hàn yìí àti ajá àti ọmọ ni àwọn ọ̀rọ̀ tí ó kọ́ra bí ẹ̀wọ̀n nínú ìsọ̀rí àrọ̀ kejì. Bí wọn ṣe ń so ohun tuntun mọ́ àwọn tí ó wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ nìyí títí ó fi dé ìsọ̀rí karùn-ún. Ní ìsọ̀rí karù-ún ni a ti wá rí ẹ̀kún rẹ́rẹ́ àrọ̀ náà bí a ti i fi hàn yìí:

A **pòrùn**
**Òrùn** òrùn kọ̀
**Òrùn** kò lá**mi**
**Omi** omí kọ̀
**Omi** kò pa**ná**
**Iná** iná kọ́
**Iná** kò jó**gi**
**Igi** igi kọ̀
**Igi** kò n**ajá**
**Ajá** ajá kọ́
**Ajá** kò jẹmí **ọmọ**
**Ọmọ** ọmọ kọ̀
**Ọmọ** kò ṣumí ire



## 4.3 Òwe

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní òwe ni ẹṣin ọ̀rọ̀, bọ̀rọ̀ bá sọnu, òwe ni a fi í wá a.Ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ tó tinú àròjinlẹ̀ wá ni òwe. Òwe ni ìpèdè tí a fi í ṣàkàwé ohun kan lọ́nà tí yóò gbà yéni yékéyéké. Àwọn àgbàlagbà ni ó máa ń pa

òwe. Ìdí nìyí tí a fi máa ń pa á ní òwe pé, "Ẹnu àgbà ni obì í gbó sí." Kì í ṣe pé àwọn ọmọdé náà kì í pa òwe, bí ọmọdé bá fẹ́ pa òwe ní ìṣojú àwọn àgbà, ó gbọ́dọ̀ fi ọkàn ìrẹ̀lẹ̀ hàn nípa sísọ pé, "Ẹ̀yin àgbà ló sọ pé.......", "Ọ̀rọ̀ lọ̀rọ̀ àwọn àgbà tó sọ pé..." àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ, kí ó tó wá pa òwe tí ó fẹ́ pa. Bí ó bá ti pa òwe tán kí ó tó rántí láti ṣèbà àgbà níbẹ̀rẹ̀, ó gbọ́dọ̀ sọ pé, "Tótó ó ṣe bí òwè àwọn àgbà". Àwọn àgbà tó bá wà ní ìkàlẹ̀ náà á sì sọ pé, "Wà á rí òmíràn pa." Òníbàjẹ́, ọ̀yájú, aláìlẹ́kọ̀ọ́ tàbí aṣa ni wọ́n ka ọmọdé tó bá pòwe níwájú àgbà tí kò jùbá sí. Àwọn àgbà ni a kà sí ọlọ́gbọ́n àti ọ̀mọ̀ràn, tí wọ́n mọ ìtumọ̀ òwe, nítorí ìrírí oríṣiríṣi tí wọ́n ti ní nínú ayé. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi máa ń sọ pé, "Ẹnu àgbà lobì í gbó sí," bí a ti sọ. Nítorí náà, ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tí àwọn àgbà ilẹ̀ Yorùbá máa ń fi í ṣàkàwé ọ̀rọ̀, èyí tó jẹ́ pé àwọn àgbà yìí náà ni ó máa ń mọ ìtumọ̀ rẹ̀, tí wọ́n sì ń máa ń lò wọ́n nínú ọ̀rọ̀, kí àwọ́n ọmọdé le ní òye nípa ìlò wọn, ni òwe.

Oríṣiríṣi ni àwọn ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tí a ka sí òwe yìí, àwọn kan wà tó jẹ́ pé láti inú ẹ̀kọ́ ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ kan tó ṣẹlẹ̀ látijọ́ ni wọ́n. Àwọn òwe báwọ̀nyí ni àwọn òwè tó jẹ́ pé ìtàn ni orísun wọn. Irú awọn yìi ni a tún mọ̀ sí ìtàndòwe. Àpẹẹrẹ irúfẹ́ òwe yìí ni, "Ó kù dẹ̀dẹ̀ kí á gbé Iwì dé Akẹ́sán, Ọba Jáayin tẹ́rí gbaṣọ," "Ọmọdé gbọ́n, àgbà gbọ́n la fi dá Ile Ifẹ̀," "Bí ènìyàn ò ṣe bí aláàárù lÓyìngbò, kò le ṣe bí Adégbọrọ̀ lỌ̀jà Iba" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn òye kan wà tó jẹ́ pé láti inú òtítọ́ ọ̀rọ̀ àti àkíyèsí ìṣẹ̀lẹ̀ ilé ayé ni wọ́n ti jẹ jádé. Àpẹẹrẹ irú àwọn òwe yìí nìyí, "Ìbínú ò mọ̀ pé olówó òun ò lẹ́sẹ̀ nílẹ̀," "Ènìyàn tó ṣu sọ́nà lálọ, yóò bẹ́ṣinṣin lọ́nà lábọ̀," "Ń ó gbẹ́ é rébété, pọ́n-ún níí kán" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn òwe kan wà tó jẹ́ pé láti inú ìwoye ènìyàn nípa àbùdá àwọn ohun àyíká ni wọ́n ti jẹ yọ. Àpẹẹrẹ ni ìwọ̀nyí, "Adìẹ ì bá lọ́kọ́, kò bá fi àkìtàn ṣe nǹkan," "Àràbà ni bàbá, ẹni a bá lábà ni baba,""Ìdí nikú ìgbín, orí nikú ahun," "Fúnra ọ̀nà níí júwe bí a ó ṣe rin ín" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ìtumọ̀ méjì ni òwe máá ńsábàá ní. Àkọ́kọ́ ni ìtumọ̀ ìdúrófún, èyí ni ìtumọ̀ ní eréfèé. Èkejì ni ìtumọ̀ ìjásí. Ìtumọ̀ ìjásí ni ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ tí òwe máá ń ní. Ìtumọ̀ ìdúrófún ni ìtumọ̀ ní eréfèé, ìtumọ̀ àkọ́kọ́ tí òwe le ní. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ yìí, "Ṣòkòtò tó ń ṣíṣẹ́ àrán, oko ló ń gbé". Àworán oríṣìí ẹ̀wù méjì ni a fi èdè yàwòrán rẹ̀ nínú òwe yìí. Àkọ́kọ́ ni ṣòkòtò, tí ó jẹ́ ẹ̀wù tàbí aṣọ iṣ, dúró fún. Ìkejì sì ni àrán, tí ó jẹ́ ẹ̀wù tàbí aṣọ ìmúròde dúró fún. Nígbà tí àgbẹ̀ bá ń ṣiṣẹ́ lóko, ṣòkòtò tó dọ̀tí ni ó máa wọ̀, wọn kì í mú ṣòkòtò náà wá sílé, inú abà ni wọ́n máa ń fi sí torí pé a máa dọ̀tí. Bí iṣẹ́ àgbẹ̀ bá wá yọrí, tí àgbẹ̀ jèrè níbi irè oko rẹ̀, a wá lọ ra àrán tó jẹ́ aṣọ olówó ńlá. Yóò wọ̀ ọ́ lọ sí òde láti lọ fi gbàyì. Lótìítọ́ ni àrán gbayì lára àgbẹ̀ tàbí pé ó mú iyì àti ẹyẹ bá àgbẹ̀ ṣùgbọ́n òtítọ́ ìdí ọ̀rọ̀ náà ni pé, ṣòkòtò tó ṣiṣẹ́ rẹ̀ wà lóko. Bí a bá wo ìtumọ̀ ìjásí òwe náà, a lè fi ṣòkòtò tó wà lóko wé àwọn òbí tó ń tọ́mọ lọ sí ilé ẹ̀kọ́ ńlá, bóyá àgbẹ̀kùàbà tàbí oníṣẹ́ ọwọ́ mìíràn, tí kò wu ojú rí tó nǹkan ni àwọn òbí ọmọ yìí. Nígbà tí ọmọ bá wá di oníṣègùn òyìnbó, tó di adájọ́, òun a wá di àrán, tó dúró fún ẹni ìyì. Àwọn òbí tó jìṣẹ́jìyà lorí ọmọ tó di gbajúmọ̀ wà lábùlé. Ṣàṣà ni òwe tí kò

ní irú ìtumọ̀ méjì yìí nítorí pé àkàwé ọ̀rọ̀ ni òwe; àfiwé àti àfidípò mni í máa wà nínú rẹ̀.

Oríṣìíríṣìí ni àwọn àbùdá òwe Yorùbá, àwọn tí a máa jíròrò lé lórí nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni, iṣẹ́ ìtọ́nisọ́nà tí òwe ń ṣe àti àbùdá aláwẹ́ méjì.

### 4.3.1 Iṣẹ́ Ìtọ́nisọ́nà

Iṣẹ́ kan pàtàkì tí òwe ń ṣe ni iṣẹ́ ìtọ́nisọ́nà láwùjọ. À máa ń fi òwe tọ́ ènìyàn sọ́nà, tí ẹni bẹ́ẹ̀ kò fi níí ṣìnà. Gẹ́gẹ́ bí òwe Yorùbá tí a pa lókè pé "Bí òwe, bí òwe ni à ń lùlù ògìdìgbó; ọlọ́gbọ́n níí jó o, ọ̀mọ̀ràn níí mọ̀ ọ́n." Òwe le korò létí ènìyàn ṣùgbọ́n òtítọ́ ọ̀rọ̀ fún ìtọ́nisọ́nà ní ó máa ń jẹ́. Àgbàlagbà rere kì í máa wò ọ̀rọ̀ níran títí nǹkan yóó fi bàjẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá. Ìdí nìyí tí wọn fi í máa pa òwe pé "Àgbà kì í wà lọ́jà kí orí ọmọ tuntun ó wọ́."Bí wọ́n bá ti ṣe àkíyèsí pé ọmọdé kan ń hùwà tó le fa ìṣubú fún un, wọ́n á pè é, wọn yóò sì fi ọ̀rọ̀ wé ọ̀rọ̀ fún un, kí ó má ṣe ara rẹ̀ leṣe. Wọn a máa lo òwe ní irú àsìkò yí Bí àwọn àgbàlagbà bá rí ọmọdé tàbí ènìyàn tí ó ń hùwà ìgbéraga, wọn yóò pe olúwarẹ̀, wọn yóò sì ṣe àlàyé ewu tó wà níbi ìgbéraga tó ń ṣe fún un. Lára àwọn òwe tí wọn ó pa fún un náà ni "Àṣẹ̀ṣẹ̀ yọ ọ̀gọ́mọ̀ tó ní òun ó kànrun, ìran rẹ̀ mélòó ló ṣerú ẹ̀ rí?", "Ọmọdé tó lẹ́nu àgbà ń rùn, ibi tó ń rè ló ń kán an lójú," " Ìgbéraga ni ìgbéraṣánlẹ̀" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí awọn àgbà bá rí ènìyàn tó ń jalè tàbí tí ó ń hu àwọn ìwà ìbàjẹ́ mìíràn, lára àwọn òwe tí wọn yóó fi tọ́ ọ sọ́nà nìyí, "Ènìyàn kì í tàja erùpẹ̀, kó má gbowó òkúta," "Ọjọ́ gbogbo ni tolè, ọjọ́ kan ni tolóhun," "Ìjàkùmọ̀ kì í rìnde ọ̀sán, ẹni a bí ire kì í rìnde òru," "Ènìyàn tó tafà sókè yídó borí, bí ọba ayé ò rí ọ tọ̀run ń wò ọ́" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìtọ́nisọ́nà ni òwe wà fún, láti fini mọ̀nà ìwà ọmọlúwàbí láwùjọ. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi ń fi òwe gba ènìyàn ní ìmọ̀ràn. Kò wá sí ọ̀ràn kan láyé tí Yorùbá kò ní òwetó bá a mu,tíàwọn àgbàlagbà máa ń fi gbaninímọ̀ràn fún ìtọ́nisọ́nà. Èyí ni Yorùbá fi ń pa á lówe pé, "Àgbà kò sí, ìlú bàjẹ́, baálé ilé kú ilé dahorò." Ìwúlò iṣẹ́ ìtọ́sọ́nà tí àwọn àgbà Yorùbá ń fi òwe ṣe ni òwe yìí ń tọ́ka sí.

### 4.3.2 Àbùdá Alábala Méjì

Gbogbo òweYorùbá ni a lè pín sí abala mejììbẹ̀rẹ̀ àti abala ìparí. Bí ẹni tí ó pa òwe bá ti mẹ́nu lé abala ìbẹ̀rẹ̀, ni ẹni tí wọ́n pa òwe fún yóò ti mọ abala ìparí sínú ara rẹ̀. Nígbà míràn ẹni tí apa owe fún náà tilẹ̀ lè bá a pari rẹ̀. Òwe Yorùbá tí ó sọ wí pé, "Ààbọ̀ ọ̀rọ̀ là á sọ fún ọmọlúwàbí, bí ó bá dé inú rẹ̀ ó máa ń di odindi" tọ́ka sí èyí.Ọpọ̀lọpọ̀ òwe Yorùbá ni ó máa ń jẹ́ aláwẹ́ méjì. Ẹ jẹ́ kí á wo àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí:

| | | |
|---|---|---|
| 1. | Awẹ́ 1: | Ọwọ́ ọmọdé kò tó pẹpẹ |
| | Awẹ́ 2: | Tàgbàlagbà ò wọ kèrègbè |
| 2. | Awẹ́1: | Gbẹ̀dẹ̀ bí ogún ìyá |
| | Awẹ́ 2: | Anini lára kókó bí ogún baba |

| | | |
|---|---|---|
| 3. | Awẹ́ 1: | Bẹ̀wẹ̀ kó o rí ọ̀kọ̀ṣẹ́ |
| | Awẹ́2: | Ṣagbe kó o rísẹ́ ahun |
| 4. | Awẹ́ 1: | Ìdí nikú ìgbín |
| | Awẹ́ 2: | Orí nikú ahun |
| 5. | Awẹ́ 1: | Bíná bá jóni jọ́mọ ẹni |
| | Awẹ́ 2: | Tara ẹni là á kọ́ gbọ̀n |
| 6. | Awẹ́ 1: | Kínlàǹfààní orógbó, |
| | Awẹ́ 2: | A pa á kò láwẹ́, a jẹ́ ẹ́ ó kòrò. |

Nígbà tí òwe kan bá gùn, ìgekúrú rẹ̀ ni a máa ń sábà pa.
Ìgékúrú yìí ni ó sì máa ń sábàá ní abala méjì yìí.
Ẹ̀dà kíkún àpẹẹrẹ òwe 1 òkè yí ni
Ọwọ́ ọmọdé kò tó pẹpẹ
Tàgbàlagbà kò wọ kèrèǹgbè,
Ọ̀wẹ̀ ewé bá bẹ àgbà kí àgbà má kọ̀ mọ́,
Gbogbo wa la jọ níṣẹ́ tí a jọ ń bẹra wa.
Àwọn irú àpẹẹrẹ bẹ́ẹ̀ míràn ni, àpẹẹrẹ 7 dé 9 ìsàlẹ̀ yí:

7. Àgìdímàlàjà awo Ilé Ifẹ̀,
Awo ní í gbáwo nígbùnwọ́
Bí awo kò bá gbé awo nígbùnwọ́,
Awo a tẹ́.

8. Orógbó rẹ́ni túndí ẹ̀ ṣe,
Ó ń fi òbùró ṣẹ̀sín
Òbùró ìbá rẹni túndíí è ṣe
À má sunwọ̀n jorogbó lọ

9. Ìlọ́ yá,OníbodèApòmù
A kó o nífà
A gbà á láya,

Ọ̀pẹ̀lẹ̀ tí ìbá tún fi ṣàyẹ̀wò,
Ajá tún gbé e lọ.

Nínú àwọn àpẹẹrẹ 7, 8 àti 9 gẹ́gẹ́ bíi ti 1 a rí i pé ìlà méjì àkọ́kọ́ ni ìgékúrú ẹ̀kún rẹ́rẹ́àwọn òwe náà. Bí a ti ṣe àlàyé nípa àpẹẹrẹ 1 níbẹ̀rẹ̀, ìlà kìn-ín-ní ni yóò jẹ́ abala kìn-ín-ní tí ẹni tí ó pa òwe yóò sọ tí ìlà keji yóò sì jẹ́ abala kejì tí ẹni tí ó gbọ́ òwe yóò mọ̀ sínú. Bí a bá wo ìyókù àwọn òwe yìí dáadáa, a ó rí i pé àlàyé síwájú sí i nípa ohun tí a ti sọ nínú àwọn ìlà méjì àkọ́kọ́ wọ̀nyẹn ni wọn jẹ́.Ẹni tí ó bá gbọ́ òwe dáadáa ni yóò mọ ìyókù yẹn tán.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ewì àrángbọ́ kéékèké (àlọ́ àpamọ̀, àrọ̀ àti òwe) ni a jíròrò lé lórí nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. A fún àwọn ewì àrángbọ́ wọ̀nyí ní oríkì, a ṣàlàyé àwọn àbùdá wọn pàtàkì pàtàkì, a wo àwọn aṣàmúlò wọn, a wo àkókò tí wọ́n ń lò wọ́n. A sì ṣe àlàyé nípa ìwúlò wọn.

- Àwọn àbùdá àlọ́ àpamọ̀ tí a jíròrò lé lórí ni bátànì ìbéèrè àti ìdáhùn àti àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tó jinlẹ̀.
- Ìhun àgbékalẹ̀ àti èrò inú àwọn ìpèdè inú rẹ̀ tí ó máa ń rọ̀ mọ́ ara wọn ni àbùdá àrọ̀ pàtàkì tí a gbé yẹ̀wò.
- Àbùdá ajẹmọ́ ìhun òwe tí a jíròrò lé lórí ni àbùdá alábala méjì, àti iṣẹ́ ìtọ́nisọ́nà tí òwe ń ṣe.
- Lára ìwúlò àlọ́ àpamọ̀ àti àrọ̀ tí a mẹ́nu bà ni pé wọ́n wà fún pípe àkíyèsí ọmọdé sí àwọn ohun àyíká wọn. Wọ́n tún jẹ́ ọ̀nà láti kọ́ ọmọ ní èdè. A tún sọ pé ọ̀nà ìdánilárayá pàtàkì ni àlọ́ àpamọ̀ àti àrọ̀ jẹ́ fún àwọn ọmọdé. A fi kún àlàyé pé a ń lo òwe láti fi ṣe àlàyé ọ̀rọ̀, à sì ń lò ó fún ìtọ́nisọ́nà.

  tọ́ka sí i pé, àwọn àrángbọ́ kéékèké wọ̀nyí máa ń jẹyọ nínú ara wọn. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, òwe le jẹyọ nínú àrọ̀. A sì ti mẹ́nu bà bí ó ṣe jẹ́ pé a rí ẹ̀yà àrọ̀ kan tí a máa ń pa bí àlọ́.Èyí ni àrọ̀ aláàlọ̀ọ́ ní ìbámu pẹ̀lú àkíyèsí Ògúpòlù (1990). Àkíyèsí mìíràn ni pé nínú àwọn àrángbọ́ kéékèké mẹ́ta yìí, òwe nìkan ló jẹ́ pé àgbàlagbà ni aṣàmúlò rẹ̀ jùlọ. Tọmọdétàgbà ló ń pa àlọ́. Tàgbàtèwe sì ni àṣàmúlò àrọ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ṣe àlàyé àbùdá àlọ́ àpamọ̀ pàtàkì méjì.
2. Àbùdá pàtàkì wo ni a fi ń dá àrọ̀ mọ̀? Ló àrọ̀ kan tí ó mọ̀ dájú láti ṣàlàyé àbùdá náà.
3. Àjọṣepọ̀ wo ló wà láàárín àlọ́ àpamọ̀ àti àrọ̀?
4. Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyénípa ìwúlò òwe láwùjọ Yorùbá.
5. Jíròrò lórí àbùdá ajẹmọ́ ihun òwe tí o mọ̀.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adésúà, A. 1978. *Àlọ́ o.* Daystar Press,Ìbàdàn.

Agbájé, B. 2013. *Àlọ́ Nínú Àṣà Yorùbá.* Elyon Publishers, Iléṣà.Ògúndèjì, P.A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. University of Ìbàdàn Centre for External Studies, Ìbàdàn.

Ògúnpòlù, B. 1986. “Classification of Yorùbá Prose Narratives”, bébà àpilẹ̀kọ tí a kà níbi àpẹrò lórí ìmọ̀ ìgbé ayé ẹ̀dá láwùjọ Yorùbá (Yorùbá Folklore Seminar), Yunifásítì Ìpílẹ̀ Ògùn, Àgọ́ Ìwòyè.

____________ 1990 “ Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Lórí Àlọ́ Àpagbè,” nínú Afọlabí Ọlábímtán (olóòtú) *Aáyan Àwọn Ọ̀mọràn lórí Ìmọ̀ ìjinlẹ̀ Yorùbá.* J. F. Ọdúnjọ Memmorial Lectures,Lagos.

Ajíbádé G. O. Àti Rájí, S.M. 2014. *Mo Járọ́, Mọ járọ̀.* Krownkom Publishers, Iléṣà.

# ÌPÍN 3 ÌṢÀRÉ AJẸMẸ́SÌN

## AKÓÓNÚ


1.0 Ìfáárà
2.0 Èròńgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    4.1 Ìjálá
        4.1.1 Oríkì
        4.1.2 Ìtàn Sísọ
        4.1.3 Ìwéréùnde
        4.1.4 Orin
    4.2 Ẹ̀ṣà Egúngún
        4.2.1 Ìjúbà
        4.2.2 Ìfira-ẹni-hàn
        4.2.3 Oríkì
        4.2.4 Ìwéréùnde
        4.2.5 Ìdágbére
    4.3 Ìyẹ̀rẹ̀ Ifá
        4.3.1 Kíké sí Àwọn Awo
        4.3.2 Ìjúbà
        4.3.3 Bíbá Òǹwòran Sọ̀rọ̀
        4.3.4 Ẹsẹ Ifá
        4.3.5 Orin
    4.4 Òrìṣà Pípè: Ṣàngó Pípè bí Àpẹẹrẹ
        4.4.1 Kíké sí Ṣàngó
        4.4.2 Kíki Oríkì Ṣàngó
        4.4.3 Oríkì Àwọn Ènìyàn Lójú Agbo
        4.4.4 Pípadà sí Oríkì Ṣàngó
        4.4.5 Orin Ìkádìí
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

ọ̀fun ṣíṣe ni a fi máa ń ṣàgbékalẹ̀ ìṣàré. Yàtọ̀ sí àbùdá àjẹmọ́ ohùn yí, àwọn àbùdá ajẹmọ́ ọ̀gangan ipò àwọn ìṣàré náà ni a tún lè fí pààlà sáàrin wọn. Ìwọ̀nyí sì ni a fẹ́ tẹnu mọ́ ní ìhín. Ìdí tí a fi ṣàpèjúwe ọ̀wọ́ àwọn ìṣàré ti a óò gbé yẹ̀wò náà bí ajẹmẹ́sìn ni pé ìdí ìsìn òrìṣà ni ojúlówó ibi tí a ti máa ń bá wọn pàdé. Ó yẹ kí á pe àkíyèsí sí i pé lóòtọ́ ni a sọ pé àwọn ìṣàré yìí jẹ mẹ́sìn, ṣùgbọ́n èyí kò sọ pé wọn kì í lò ó fún ayẹyẹ àríyá nígbà míràn. Nígbà tí èyí bá wáyé ṣá, àwọn ẹlẹ́sìn òòṣà tí ó ni ìṣàré náà ni yóò máa ṣàmúlò rẹ̀ níbi àríyá tí ó jẹ́ tiwọn.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Nígbà tí o bá ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán, o ó ti lè ṣàlàyé nípa ọ̀gangan ipò àwọn ìṣàré tí a óò jíròrò lé lórí bí i ìjálá, ẹ̀ṣà egúngún, ìyẹ̀rẹ̀ ifá àti àwọn òrìṣà pípè pàápàá Ṣàngó pípè. O ó ti lè jíròrò nípa àwọn aṣàmúlò, àkókò ìṣeré, ètò ìṣeré, ohun èlò orin tí wọ́n ń lò sí wọn lọ́kọ̀ọ̀kan àti àkóónú ìkọ̀ọ̀kan wọn.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. a.) Àwọn òrìṣà Yorùbá wo ni wọ́n ni ìṣàré wọ̀nyí: ìjálá, ẹ̀ṣà àti ìyẹ̀rẹ̀?
   b.) Ọ̀rọ̀ ìṣe wo ni à ń lò láti fi sọ bí a ṣe ń ṣe ìgbékalẹ̀ wọn.
2. Àwọn wo ni aṣàmúlò Ṣàngó pípè, ẹsẹ ifá, ẹ̀ṣà àti ìyẹ̀rẹ̀?
3. Ní ṣókí ṣàlàyé àbùdá tí ó ya ìyẹ̀rẹ̀ sọ́tọ̀ láàrin àwọn ìṣàré yòókù.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìjálá

Ìjálá ni ewì alohùn tí àwọn ẹlẹ́sìn Ògún máa ń sun láti fi gbóríyìn fún Ògún nígbà tí wọ́n bá ń bọ ọ àti níbi àwọn ṣiṣé tàbí ayẹyẹ tó níiṣe pẹ̀lú Ògún àti àwọn olùsìn rẹ̀. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa tún ń pè ìjálá ní aré Ògún. Nítorí pé àwọn ọdẹ ni ó gbajumọ̀ jù láàrin àwọnológùn-ún ni wọn tún fi máa ń pe é ní aré ọdẹ, pàápàá èyí tí ójẹ́ pé àwọn ọdẹ ni wọ́n ń sun ún. Ìgbàgbọ́ àwọn olùsìn Ògún ni pé Ògún ni ó dá ìjálá sílẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Babalọlá (1966), Ògún pe àwọn ọmọ rẹ̀ lọ́jọ́ kan pé kí wọn máa ki òun láti fi mú inú òun dùn, àrẹmọ rẹ̀ sì kì í ní ọ̀nà àrà-ọ̀tọ̀, èyí ni ó sì di ìjálá títí di òní. Báyìí ni ìjálá sìsun ṣe bẹ̀rẹ̀. Àwọn olùsìn Ògún gbàgbọ́ pé bí àwọn bá ń sun ìjálá, inú Ògún yóó dùn máa sí àwọn, àwọn yóò sì máa túbọ̀ rí ojúrere rẹ̀ gbà. Àwọn olùsìn Ògún, yálà lọ́kùnrin tàbí lóbìnrin tó máa ń sun ìjálá ni àwọn ọdẹ, àwọn alágbẹ̀dẹ, àwọn olóòlà, àwọn jagunjagun, àwọn warinwarin àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lára àwọn àkókò tí wọ́n tí máa ń sun ìjálá ni ìgbà tí wọ́n bá ń ṣe ọdún Ògún, ibi Ògún bíbọ, ní oko ọdẹ, lẹ́nu iṣẹ́ arọ́, níbi ìpàdé àwọn ọlọ́dẹ tàbí tàwọn alágbẹ̀dẹ tàbí àwọn olóòlà, pẹ̀lú ibi ìpàdé iṣẹ́ àwọn ènìyàn yòókù tí iṣẹ́ wọ́n jẹ mọ́ Ògún. Ìlù àgẹ̀rẹ̀ ni ìlù tí a máa ń lù sí ìjálá. Kò sí ìgbà tí àwọn ọdẹ kì í sun ìjálá ní ti wọn.Nígbà tí àwọn ọdẹ bá wà ní oko ọdẹ ni àkókò pàtàkì tí wọn máa ń sùnjálá. Bí wọ́n bá ń sun ìjálá ní oko ọdẹ, tí kò sì sí ìlù àgẹ̀rẹ̀ ní ibẹ̀, wọ́n máa ń fọn fèrè ekùtù tàbí tòròmagbè sí i. Àṣà yìí máa ń wáyé nínú àwọn aré ọdẹ tí a ṣe láàrin ìlú náà o. Kì í ṣe pé oko ọdẹ nìkan ni wọ́n ti ń fọn ekùtù sí ìjálá sísun. Àwọn ọdẹ a máá fi ìjálá bá ara wọn sọ̀rọ̀, wọn a máa fi dáwọ̀ọ́ ìdùnnú bí ọwọ́ bá dẹ, wọn a sì máa fi dárò bí igbó bá ro fún ọdẹ. Ìrèmọ̀jé ni ẹ̀yà ìjálá tí àwọn ọdẹ máa ń sun láti dárò ọdẹ tí ó papò dà, pàápàá ní àkókó orò ìdágbéré ìkẹyìn tí à ń pè ní ìpà ọdẹ. Ìdí nìyí tí àwọn asùnjálá fi máa ń sọ pé,

Ìrèmọ̀jé kì í ṣorin ìgbàkúùgbà,
Kì í ṣorin tá à á gbọ́dẹ̀dẹ̀ ẹnií kọ.
Kì í ṣorin tí à á kọ nígbà orin bá ń wuní kọ.
Orin tí à á kọ nígbà tó bá ṣòro fún ọdẹ ni. (Àjùwọ̀n, 1981: 9)
Pàtàkì lára àwọn àkóónú ìjálá ni: oríkì, ìtàn sísọ, ìwéréùnde àti orin.

### 4.1.1 Oríkì

Kò sí ìṣàré tí oríkì kì í ti í jẹyọ, ṣùgbọ́n ìkọ̀ọ̀kan ló ní irú oríkì tí ó wọ́pọ̀ jùlọ nínú rẹ̀. Kò yani lẹ́nu pé oríkì Ògún ni ó ṣe pàtàkì jùlọ nínú ìjálá nítorí pé aré Ògún ni Ìjálá. Yàtọ̀ sí oríkì Ògún,inú ìjálá ni a ti máa ń bá oríkì àwọn ògbójú ọdẹ ayé àtijọ, oríkì ẹranko, ẹyẹ àti igi pàdé. Ẹ jẹ́ kí á wo oríkì Ògún tí ó jẹyọ nínú àpẹẹrẹ 1 ìjálá tí Yémiítàn pè ní "Àpọ́nlé Ògún."

1. Atótó arére,
   Pàràkòyí baba mọ̀ngánnà,
   Ní ijọ́ tí Ògún ń torókè bọ̀
   Mo mọ aṣo tó fi bora
   Mo sì mọ irú ẹ̀wù tó wọ̀
   Aṣọ iná lÒgún fi bora
   Ẹ̀wù ẹ̀jẹ̀ lÒgún gbé wọ̀
   Ògún ni ń ó sìn ní tèmi
   Èmí ò jẹ́ sin ọba
   Torí bí ọba bá pa mí o
   Ògún ó sì pọba san
   Ṣùgbọ́n ẹni tí yóó pa Ògún la ò mọ̀
   Torí Ògún ló lajá, òun ló làgbò
   Ògún, Onímògún, ọmọ àhúṣẹ̀
   N ó hú ilẹ̀, hú owó
   N ó hú ilẹ̀, hú sẹ̀gi
   Ọmọ adándúrókíni
   Àgbẹ̀dẹ mi fakafìkì lọ́nà tÌrè... (Yemitan, 1979: 42-43)
   Àpẹẹrẹ oríkìẹranko, ẹtu ni àpẹẹrẹ 2 ìsàlẹ̀ yìí bí Yémiítàn ṣe kì í.
2. Ẹtu láarún
   Òbèjé-ǹ-yẹkẹ
   A-bi- -tete í pe olögún ẹrú
   A-bi-ètìpá í pe ọlọ́gbọ̀n ìwọ̀fà
   A-bi-ìjáǹjá í pe aláàárù tantan
   Ẹtu mọ́sálà, ẹtu Sàlàkọ́
   Òfẹ́fẹ́-ǹfẹ́, arírù túnraṣe níwájú ọkọ (Yemitan, 1979: 56)
   Oríkì orílẹ̀ náà a máa jẹyọ nínú ìjálá. Àpẹẹrẹ kan nìyí ní ìsàlẹ̀ yìí:
3. Àgùnmọ́, ọmọ oyè Ifẹ̀
   Àbú onÍfẹ̀ Ọ̀ọ̀ni
   Àbú onÍfẹ̀ Oòrè
   Àbú oníf ẹ̀ Òǹtólú

Ọmọ akábá owó rẹmọ
OnÍfẹ̀ Agbùré, ọmọ adádé-owó rẹmọ
Ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ nÍfẹ̀ Oòrè
A kì í dúró kíni nÍfẹ̀ Ọ̀ọ̀ni
A kì í bẹ̀rẹ̀ kíni nÍfẹ̀ Oòrè
Tí a bá bẹ̀rẹ̀ kí wọn nÍfẹ̀ Ọ̀ọ̀ni
Tí a bá dúró kí wọn nÍfẹ̀ Ọ̀ọ̀ni
Tí a bá bẹ̀rẹ̀ kí wọn nÍfẹ̀ Oòrè
Ẹbọ ni wọ́n ń fi olúwa rẹ̀ ṣe!
Kò-ga-kò-bẹ̀rẹ̀ là í kíni nÍfẹ̀ Òǹtólú (Yemitan, 1979: 51-52)

Oríkì orílẹ̀ àwọn Ifẹ̀ (Olùfẹ̀) ni a kì nínú àyọlò òkè yìí. Ó ṣe é ṣe kí oríkì àwọn àgbà ọdẹ tí ó jẹ́ akọni, oríkì àwọn bọ̀rọ̀kìnípàápàá ti àwọn jagunjagun náà máa jẹyọ nínú ìjálá tí wọn bá tẹ́ pẹpẹ eré ìjálá sílẹ̀ láwùjọ.

### 3.1.2 Ìtàn Sísọ

Ìtàn sísọ jẹ́ àkòónú kan pàtàkì tí ó máa ń jẹyọ nínú ìjálá. Àwọn ìtàn tí wọ́n fi sọìdí-abájọ ẹranko, ẹyẹ, ewéko pẹ̀lú ìtàn àwọn akọni ọdẹ àtijọ́ àti ti ìtẹ̀dó ìlú náà máa ń jẹyọ nínú ìjálá. Àpẹẹrẹ irú ìtàn ìjálá báyìí ni èyí tí wọ́n fi sọ ìdí abájọ bí ọta àti àhàyá ṣe dé Ifẹ̀ nínú ìtàn “Ọmọwọ́nmi Wọlẹ̀ Ní Ilé-Ifẹ̀” (Yemitan, 1979:1-2). Bákan náà ni “Ìtàn Ọdẹ́jọbí” (Yemitan, 1979: 3-5) tó mú iṣu wálé láti igbó. A rí ìtàn “Ọdẹ Ilé-ayé àti tọ̀run” nínú Yemitan, (1979.4-6). Bákan náà ni ìtàn “Ọ̀jẹ́wùmí tó di pẹ́pẹ́yẹ,” “Erìnmìnà ló dá Ìpà-ọdẹ sílẹ̀” àti “Ọdẹ tó ṣẹnu fóró” (Yemitan, 1979: 1215 àti 19). Gbogbo àwọn ìtàn wọ̀nyí ló jẹ́ ìtàn àwọn ọdẹ ìgbàanì tó sọ ìdí abájọ kan tàbí òmíràn tàbí láti fi bí agbára wọn ṣe tó hàn.

Àpẹẹrẹ àwọn ìtàn inú oríkì orílẹ̀ Yorùbá tí ó jẹyọ nínú ìjálá ni “Ìyàwó Aláìgbọràn” láti inú oríkì Ẹlẹ́rìn, “Ìdí rẹ̀ tí Oníkòyí Kì í fi í jẹ òkété” láti inú oríkì orílẹ̀ Oníkòyí, “Àwọn ọmọ Ọlọ́fà” láti inú ìtàn Ọlọ́fà, àti “Kúnnúwẹ́”, tó jẹ́ ìtàn ìran Oníkòyí (Yemitan, 1979: 28, 34, 35 àti 57). Lára irúfẹ́ ìtàn tó tún máa ń jẹyọ nínú oríkì inú ìjálá ni ìtàn àwọn òrìṣà. Àpẹẹrẹ èyí ni ìtàn “Ìjà Ògún pẹ̀lú Ṣàngó” (Yemitan, 1979: 45-47). [Ṣe àwárí ìwé Yemitan, 1979, kí o sì kà gbogbo àwọn ìtàn ìjálá tí a tọ́ka sí.]

### 4.1.3 Ìwéréùnde

Ìwéréùnde ni a tún mọ̀ sí ìwéùnderé tàbí ìjáǹjá. Èyí ni àríwísí àwọn asùnjálá nípa oríṣiríṣi ọ̀rọ̀ tó ń lọ ní àwùjọ. Ìwéréùndé nínú ìjálá lè jẹ́ ọ̀rọ̀ àwàdà. Ó le dá lórí ìwà ìbàjẹ́ tí àwọn ọ̀wọ́ ènìyàn kan ń hù bí irọ́ pípa, ọ̀kánjúwà, àìṣòótọ́, òjòwú, ìmẹ́lẹ́, olè jíjà, ìlọ́nilọ́wọ́gbà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àpẹẹrẹ ìwéréùnde kan nìyí tí Ògúndáre Fọ́nyánmú fi bẹnu àtẹ́ lu owú jíjẹ.

Lílé: Hàáà ọkọ́ kẹ́ran
Bóbinrin dáa bí ò níwà ọkọ kẹ́ran
Òjòwúbìnrin ò ṣé é fi ṣẹlé
Ẹjọ́ ni wọ́n fi í gbó ọkọ wọn lẹ́nu
Òjòwú ò tètè jẹ́ kárá ilé ọkọ rẹ̀ ó sùn lójú ọjọ́
Ká fòní rojọ́, ká fọla ṣàlàyé
Ká fọla ṣàlàyé
N ló sòjòwú dẹni
Tí Ò jẹ́ ǹkankan mọ́ lọ́wọ́ ọkọ rẹ
Ìyàwó tó lágídí nílé baba rẹ̀ tẹ́lẹ̀
Ó wá ń jó ijó ìyàwó lọlé ọkọ rẹ̀
Ó ró àrán agídínké
Agídí wá lọ di méjì lọ́dọ̀ ọkọ rẹ̀
Bẹ́ẹ̀ wí wí wí kò ní í fẹ́
Bẹ́ẹ̀ sọ sọ sọ kò ní í gbà
Bó bá jáàkì ẹ̀wù tán
A gógì ọrùn mọ-mọ-ọn-mọ sọ́kọ rẹ̀
Yóó máa wá jawọ́ jasẹ̀ bí àwọn ẹni tó ń hunsọ
Òjòwúbìnrin fidí ọmọ rẹ̀ jálẹ̀ kun-kun-un-kun...
Orin: Òjòwúbìnrin fẹjú toto
Ó jàjà gbọ́ pọ́kọ ń yànrẹ́, ó fẹjú toto
Ègbè: Òjòwúbìnrin fẹjú toto (Àlàgbé, 2006:1-3)

Àwọn obìnrin òjòwú ni Ògúndáre Fọ́yánmu fi ṣe ẹ̀fẹ̀ ní inú orin ìjálá òkè yìí. Abala ìwéréùnde ni àwọn eléré ìjálá tí máa ń dá àwọn ènìyàn lẹ́kọ̀ọ́ ìwà ọmọlúàbì, ibẹ̀ sì ni wọ́n tí máa ń tọ́ka sí àwọn ìwà ìbàjẹ́ àwùjọ láti fi dáni lẹ́kọ̀ọ́.

### 4.1.4 Orin

Ipa pàtàkì ni orin máa ń kó nínú ìjálá. Bí eléré ìjálá bá sun ìjálá lọ, tí ó sun ìjálá bọ̀, orin ni wọ́n fi máa ń parí rẹ̀. Kò sí àkóónú ìjálá kan tí kì í yọrí sí orin, yálà ó jẹ́ oríkì tàbí ìwéréùnde. Orin ìjálá kì í gùn, ṣokí ni ó máa ń jẹ́. Lílé rẹ̀ kì í fi bẹ́ẹ̀ ju gbólóhùn kan tàbí méjì lọ. Bí ó bá ju gbólóhùn méjì lọ, a jẹ́ pé láti ṣe àwítúnwí gbólóhùn àkọ́kọ́ tí a fi bẹ̀rẹ̀ orin náà ni. Lọ́pọ̀ ìgbà kókó inú ìṣàré tí asùnjálá bá kọ́kọ́ sun ni orin ìjálá máa ń sábàá dá lé. Ṣùgbọ́n ṣá lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan, ó lè má sí àjọse láàrin kókó ọ̀rọ̀ ìjálá tí oníjálá sun àti orin tí ó fi kádìí rẹ̀ nílẹ̀. Nínú aré ìjálá, bí ẹni tí ó ń sun ìjálá bá fẹ́ dárin, lọ́pọ̀ ìgbà, wọn a máa bèèrè lọ́wọ́ àwọn ẹlẹ́gbẹ́mọdẹ (àwọn ọdẹ tí wọ́n wà níkalẹ̀ níbi eré ìjálá náà) pé ṣé wọn ó gberin ọdẹ tàbí wọn ò ní í gberin ọdẹ tí wọn bá dá. Àwọn náà yóò sì fèsì pé àwọn yóò gberin ọdẹ. Kì í sábàá wáyé kí àwọn ẹlẹ́gbẹ́mọdẹ máa sọ pé àwọn kò ní í gberin ọdẹ. Àpẹẹrẹ àwọn ìpèdè tí wọ́n fí máa ń ṣe àgbékalẹ̀ ìbéèrè yìí nìyí ní ìsàlẹ̀ yí:

1. Lílé: Ẹlẹ́gbẹ́ mo ní ṣẹ ẹ́ gberin ọdẹ
Àbí ẹ ò gberin ọdẹ?
Ègbè: A ó gberin ọdẹ

2. Lílé: Ẹlẹ́gbẹ́ mo ní ṣẹ ẹ́ gberin ọdẹ
Àbí ẹ ò gberin ọdẹ?
Ègbè: Dárin náà kó dùn mọ́mọ́
Dárin náà kó dùn mọmọ
Orin tálùkò bá dá
Lọmọ rẹ̀ẹ́ gbè

Bí ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì yìí bá ti wáyé tán, kí asùnjálá ó dárin ló kù. Ó yẹ kí á kíyèsí i wí pé àwọn ìpèdè ìbéèrè àti ìdáhùn wọ̀nyí dúró bí i fọ́múlà tí àwọn oníjálá máa ń lò bí okùn tí ó so ìṣàré sísún pọ̀ mọ́ orin kíkọ nínú ìṣeré wọn. Àpẹẹrẹ àwọn orin inú ìjálá díẹ̀ nìyí:

1. Lílé: Ògún mámà jẹ́ n rí ṣọṣọ o
Ògún mámà jẹ́ n rí ṣọṣọ o
Ẹni wá ṣọṣọ
Á à rí ṣọṣọ
Ègbè: Ògún mámà jẹ́ n rí ṣọṣọ o

2. Lílé: NÍrẹ̀sà o, nÍrẹ̀sà
Gbogbo mọdẹ
Ègbè: NÍrẹ̀sà nilé

3. Lílé: Ta ló pe tíṣà síjó ọdẹ
Ta ló pe tíṣà síjó ọdẹ
Abi ṣòkò sofésofé
Ègbè: Ta ló pe tíṣà síjó ọdẹ

4. Lílé: Ṣèdígúlúmọ́, ṣèdígúlúmọ̀
Bóbìnrín bá ṣèdígúlúmọ́ a ríjà ẹpọ̀n
Ègbè: Ṣèdígúlúmọ́

5. Lílé: Ògún má mà fi dán wa wò,
Ògún má mà fi dán wa wò,
Ohun tó ṣàgbàdo òjò tí ò gbọ́mọ pọ̀n;
Ègbè: Ògún mámà fi dán wa wò

Àpọ́nlé Ògún ni orin 1, 2 jẹ́ orin tí a fi ṣe àpọ́nlé àwọn ọmọ Ìrẹsà. Nígbà tí wọ́n bá ń ki orílẹ̀ wọn ni àwọn oníjàálá máa ń kọ orin náa. Orin 3 àti 4 jẹ́ orin ìwéréǹde láti fi àwọn olùkọ́ ṣẹ̀fẹ̀ àti láti fi ọ̀rọ̀ wèréwèré panilẹ́rìn-ín. Ìwúre sí Ògún kí àwọ́n má yàgàn ni 5.

## 4.2.0 Ẹ̀ṣà Egúngún

Ẹ̀ṣà egúngún ni oríṣi ohùn ìṣàré tí àwọn eléégún, tí a tún mọ̀ sí ọ̀jẹ̀,máa ń pè nígbà tí wọ́n bá ń ṣe orò, ayẹyẹ tàbínibi ìṣeré àwọn eléégún aláré. Oríṣiríṣi ni orúkọ tí àwọn onímọ̀ ti fi pe ẹ̀ṣà egúngún. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ ẹ̀ṣà egúngún ni a tún mọ̀ sí iwì egúngún. Olúkòjú (1978) ṣe àlàyé ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin orúkọ mééèjì. Ó wí pé nígbà tí àwọn ọlọ́jẹ̀ wà ní àárín ara wọn, tí wọ́n ń ṣe orò tó jẹ mọ́ awo egúngún ni wọ́n máa ń pe ẹ̀ṣà ṣùgbọ́n iwì egúngún ni wọ́n máa ń kì bí wọ́n bá ń ṣeré ní àwùjọ tawotọ̀gbẹ̀rì. Olúkòjú fi kún un pé ní ọwọ́ àárọ̀, tí àwọn ọlọ́jẹ̀ bá ń múra láti jáde ni wọ́n máa ń pẹ̀ṣà, láti fi jùbà àti láti fi wá òde. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, a jẹ́ pé ẹ̀ṣà jẹ́ ewì ìjọ́sìn nígbà tí iwì jẹ́ ewì ìṣeré.

Ọlájubú (1972) kò gbà pé ìyàtọ̀ kankan wà láàrin ẹ̀ṣà àti iwì ní tirẹ̀. Ó ní ẹ̀ṣà náà ni àwọn kan ń pè ní iwì, tí wọ́n sì tún ń pè ní ògbérè ní àárín àwọn Ẹ̀gbá. Ọ̀pádọ̀tun (2002) tilẹ̀ lo orúkọ méjèèjì (ẹ̀ṣà àti iwì) láti fi dípò ara wọn ni. Kò fi ìyàtọ̀ kankan sí àárín àwọn méjèèjì. Bí a bá pe ewì yìí ní ẹ̀ṣà, pípè ni wọ́n máa ń pè é. Bí a bá pè é ní iwì, kíkì ni wọ́n ń kì í, bí ó bá jẹ́ pé ògbérè ni a pè é, sísun náà ni ọ̀rọ̀ ìṣe tí a fi ń júwe bátànì ìwọ́hùnròrò rẹ̀. Torí pé ẹ̀ṣà ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn mọ ewì alohùn yìí sí jùlọ, ẹ̀ṣà ni a ó yàn láàyò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wa. Oríṣiríṣi eégú ni ó wà. Ní àkókò ọdún eégún ni àwọn eégún alágbo, pààràká àti eégun jàǹdùkú máaǹ jáde. Ṣùgọ́n kò sí ìgbà tí àwọn eégún aláré kì í jáde láàrin ọdún tí kì í bá ti í ṣe àkókò òjò. Àwọn eégún aláré ni ó máa ń pe ẹ̀ṣà jù lọ. Iṣẹ́ aré ṣíṣe ni ojúlówó iṣẹ́ ìran wọn. Wọn kì í ṣe egúngún tí a fi ń ṣe orò egúngún, eré egúngún ni wọ́n wà fún. Kì í ṣe pé àwọn náà kì í ṣe ọ̀jẹ̀, gbogbo òfin egúngún ni àwọn náà sì gbọdọ̀ tẹ̀lé gẹ́gẹ́ bí àwọn egúngún yòókù ṣùgbọ́n o, eré ni àwọn jẹ mọ́ jùlọ, kì í ṣe orò ṣíṣe. Àwọn náà ni a tún ń pè ní eégún apidán tàbí alárìnjó (Ògúndèjì, 1992).

Bí àwọn ọkùnrin tí ó ru ẹ̀kú (tàbí agọ̀) ti le pe ẹ̀ṣà náà ni àwọn ọkùnrin tí kò ru ẹ̀kúnáàlè pẹ̀ṣà. Obìnrin ilé ọlọ́jẹ̀ náà a sì máa pẹ̀ṣà dáadáa bí wọn kò tilẹ̀ lè ru agọ̀.Wọn a máa lu ìlù bàtá sí orin àti ijó tí wọ́n máa ń fi lú ẹ̀ṣà pípé lójú agbo eré. Ohun tí ó kàn wá nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni àwọn àbùdá ẹ̀ṣà egúngún pipè àti àwọn àkóónú rẹ̀. Àwọn àbùdá ìgbékalẹ̀ ìṣeré ẹ̀ṣà pípè lójú agbo eré tí a óò yiiri wò báyìí bí Ọlájubù (1972) se gbé e kalẹ̀ tí Ògúndèjì (1991) túbọ̀ ṣe àlàyé lé e lórí ni:ìjúbà, ìfira-ẹni-hàn, oríkì, ìwéréùnde àti ìdágbéré. Ọ̀nà mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Ọlájubù tún àwọn àbùdá/ ìgbésẹ̀ àgbékalẹ̀ ìṣeré ẹ̀ṣàpín sí. Àwọn náà ni: ìbẹ̀rẹ̀ eré, àárín eré àti ìparí eré.

| | | |
|---|---|---|
| 1. | Ìjúbà | Ìbẹ̀rẹ̀ |
| 2. | Ìfira-ẹni-hàn | |
| 3. | Oríkì (Bọ̀rọ̀kìní àtiOrílẹ̀) | Ààrín |
| 4. | Ìwéréùndé | |
| 5. | Ìdágbére | Ìparí |

Ẹ jẹ́ kí áṣe àgbéyẹ̀wò àkóónú àwọn ìgbésẹ̀ náà ní ọ̀kọ̀ọ̀kan, pẹ̀lú àpẹẹrẹ láti inú ẹ̀ṣà egúngún.

### 4.2.1 Ìbà

Ìbà jíjú máa ń kó ipa pàtàkì nínú ìṣeré lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Yorùbá gbà pé "Ọmọdé ò níí rẹ́ni júbà kíbà hunmọ." Wọn a tún máa sọ pé, "Bí ekòló bá júbà ilẹ̀, ilẹ̀ á lanu." Yorùbá rí òṣèré tí kò bá júbà àwọn àgbàlagbà kó tó bẹ̀rẹ̀ eré rẹ̀ bí ọ̀yájú, ẹni tí kò mọ àṣà àti oníbàjẹ́ ènìyan. Torí èyí, wọn a máa bá òṣèré bẹ́ẹ̀ wí, ó le má bá eré rẹ̀ dé ibìkan tí wọn yóó fi ti ohùn rẹ̀ pa, wọ́n le fa òjò lé e lórí, wọ́n sì le da eré rẹ̀ rú. Bí àwọn egúngún aláré bá fẹ́ pẹ̀ṣà, wọn a máa júbà Olódùmarè, wọ́n máa ń júbà àwọn òrìṣà bí Ṣàngó, Ògún, Èṣù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ kí eré wọn ó le júṣe. Wọ́n tún máa ń júbà àwọn tó kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ awo egúngún bí Ọjọ́gbìn-ín, Ológbojò, Arúkú, Ẹ̀ṣà Ọ̀gbín, Aláràn-án àti Làgbàyí ará Ọ̀jọwọ̀n, tí a tún mọ̀ sí Ọlọ́jọwọ̀n. Wọn a tún máa ń júbà àwọn ẹlẹyẹ àti àwọn àgbààgbà bí ọba tàbí ìjòyè pàtàkì tó bá wà ní ìkàlẹ̀. Ó pọn danadan kí wọn ó júbà baba wọn, tó fi ẹsẹ wọn lénà níbi aré ẹ̀ṣà, ọ̀gá wọn àti àwọn ọ̀gá apeṣà tó wà ní ìkàlẹ̀. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìjúbà nínú ẹ̀ṣà gẹ́gẹ́ bí ó ti wà ní ìsàlẹ̀ yì:

1. Ìbà o o ò,
   Ìbà ni n ó máa fòní jú;
   Ọlọ́jọ́ òní mo yà júbà lọ́dọ̀ rẹ,
   Kí n tó máwo ṣe.
   Ìbà o o o o ò,
   Ìbà ẹni dá kí n tó dá o;
   Ìbà ẹni tẹ̀ kí n tó tẹ̀ lọ́jẹ̀,
   Ìbà ìyá mi òṣòròǹgà, olókìkí orú;
   Ìbà afínjú àdàbá tí í jẹ láàrin àṣá,
   Àfínjú ẹyẹ tí í jẹ ní gbangba oko,
   Ìbà ọmọ afòrurìn.(Ọlajubu, 1972:8)s
2. Agbe ó lahùn, a lahùn aró ò
   Baba à mi, àlùkò lahùn, a lahùn osùn o
   Mo fẹ́ ẹ́ lahùn lónìí
   Babaà mi pàrá nidàá wàkọ̀
   Mo ríbá mo ríbàa bóge
   Ìbàá mi, ìbàa bòge

Mo ríbà Èṣù tán mo ríbà Ṣàngó
Mo ríbà ìyáà mi
Ajíbọ́lá ọlọmọ
Ìyá mi Àbẹ̀ní ọmọ Oyè mọ Afẹ̀sọ̀wẹ̀ (Ọ̀pàdọ̀tun, 2002: 50)

Nínú àpẹẹrẹ 1 òkè yìí, apẹ̀ṣà àkọ́kọ́ júba Olódùmarè tó pè ní Ọlọ́jọ́ òní. Lẹ̀yìn náà ni ó júbà àwọn àjẹ́. Bákan náà ni apẹ̀ṣà kejì júbà baba rẹ̀, ó júbà bóge, ó sì júbà bòge, ó júbà Èṣù, ó sì júbà Ṣàngó, lẹ̀yìn èyí ni ó júbà àwọn àjẹ́. Àwọn àjẹ́ ni ó pè ní Ajíbọ́lá Ọlọmọ, a tún máa ń pe Ẹdan Ògbóni náà ni Ajíbọ́lá Ọlọmọ. Ohun tó mú àwọn apẹ̀ṣà júbà bí wọ́n ṣe júbà yìí ni pé, kí eré ó le yẹ wọ́n, kí wọ́n sì ṣàṣeyege nínú eré náà.

### 4.2.2 Ìfira-ẹni-hàn

Bí àpẹṣà bá ti júbà tán, dandan ni kí ó fira rẹ̀ hàn. Nínú ìfira-ẹni-hàn yìí ni apẹ̀ṣà yóó ti sọ orúkọ rẹ̀, orúkọ baba rẹ̀, orúkọ ìyá rẹ̀ nígbà mìíràn, ìran tàbí ìlú tí ó ti ṣe ọ̀jẹ̀ wá. Ìfira-ẹni-hàn yìí ṣe kókó. Nínú ìfira-ẹni-hàn, àwọn egúngún aláré máa ń sọ nípa ìrírí wọn, ìṣòro tí wọ́n ti kojú àti àwọn àṣeyọrí tí wọ́n ti ṣe. Ṣíṣe àpọ́nlé ar ẹni ni ìfira-ẹni-hàn jẹ́ nínú ẹ̀ṣà pípè.Nípasẹ̀ ìfira-ẹni-hàn ni a ṣe le mọ̀ nípa apẹ̀ṣà dáradára kí ó tó bá aré rẹ̀ lọ jìnnà.Àpẹẹrẹ ìfira-ẹni-hàn niyí ni ìsàlẹ̀ yìí:

1. Mo dé bémi ti í dé,

Ọmọ Mopénúọlá,
Mofóyèkẹ́ Àyọ̀ká,
Kólóko má leè roko.
Àyọ̀ká dé o,
Kọ́lọ́nà má yẹ̀nà,
Ìyáọlá Àyọ̀ká dé,
Kọ́kọláyà má sùn tira wọn.
Wọ̀ọ̀bíọjọ́rọ̀ ọkọ ìyá Alárápé (Ọlajubu, 1972: 9)

2. Èmi lọmọ arísẹ̀gi ṣògbóni
Ọmọ òbunimọ̀ bunimọ̀ ṣojú konkoÌyáà mi lògbóni
Babaà mi lapènà
Èmi pàá mo kẹ́kùn, mo ṣÒgbóni mọ́wọ́
Èyí tí ó ṣààfàànì nínú Lédì ọmọ ìmùlẹ̀
Ó di wẹ́kú, ó di wẹ́mú ò
Ọ̀jẹ́níhún Àwẹ̀ní, mo ríbà babaà mi
Ṣọjẹ̀ má bọ́jẹ̀ jẹ́, Ọlọ́jẹ́ ọmọ Ọ̀jẹ́gbilé
Ṣọjẹ̀ má bọ́jẹ̀ jẹ́ ọmọ Ọ̀jẹ́lẹ́yẹ
Ìsàlẹ̀ Ìlàká nilé àwọn babaà mi
Èmi lọmọ Olúkókun Àjàdó Ẹlẹ́rìnmọ̀sá
Nílé Kọ́lédọyẹ́, mo mọ̀ ṣọyẹ́ tán n tóó ṣooru
Mo ṣerì wọ̀wọ̀ padà lẹ́sẹ̀ òkè.... (Ọ̀pàdọ̀tun, 2002: 50)

Nínú àyọ̀lò 1, apẹ̀ṣà jẹ́ ká mọ̀ pé ọmọ Mopénúọlá ni òun. Òun ni Mofóyèkẹ́ Àyọ̀ká(gbajúgbajà apẹ̀sà obìrin ọmọ eléégún aláré kan tí í jẹ́ Àjàǹgìlání ìlú Ìbàdàn). Ó pọ́n ara rẹ̀ lé wí pé tí òun bá ń pẹ̀sà níbìkan gbogbo ènìyàn ni yóò fẹ́ wòran òun dé ibi wí pé ẹni tó fẹ́ lọ ṣiṣẹ́ lóko kò ní lè lọ sóko mọ́, kódà ọkọ kò ní í ráyè láti sùn ti ìyàwó rẹ̀ náà mọ́.. Apẹ̀ṣà kejì jẹ́ kí á mọ̀ pé ọmọ olóyè pàtàkì láàrín awo ògbóni ni òun. Ó jẹ́ kí á mọ̀ pé àti baba àti ìyá òun ni ó ológbóni. Ó jẹ́ kí á mọ̀ pé ìdílé ọ̀jẹ̀ ni òun ti wá. Ó fi yé wa pé ọmọ Ọ̀jẹ́gbilé àti Ọ̀jẹ́lẹ́yẹ ni òun. Ó tún júwe àdúgbò rẹ̀ pé Ìsàlẹ̀ Ìlàká ni òun ti wá. Lẹ́yìn èyí ló sọ pé, Ẹlẹ́rìnmọ̀sá ni oríkì orílẹ̀ ilé àwọn baba òun ní agboolé Kọ́lédọyẹ́. Nígbà tí àwọn òǹwòran bá ti mọ èyí, ìbáṣepọ̀ wọn pẹ̀lú apẹ̀ṣà yóó yátọ̀ sí tí wọn kò bá mọ̀ ọ́n rárá. Torí pe ó ti sọ pé òun jẹ́ ọmọolóɡbòóni, ó di dandan kí gbogbo àwọn àgbààgbà ògbóni tó bá wà ní ibi ìṣeré náà, ó fojú rere wò ó, torí awo kan náà tí wọ́n jọ ń ṣe.Ṣé awo ní í kúkú gbáwo nígbùnwọ̀ tẹ̀lẹ̀..., bí òwe àwọn àgbà.

### 4.2.3 Oríkì

Abala oríkì ní í máa pọ̀ jùlọ nínú ẹ̀ṣà pípè. Bí apẹ̀ṣà bá ti ṣe ìjúbà tán, tí ó sì ti fi ara rẹ̀ hàn, láti ibi ìfira-ẹni-hàn ni oríkì orílẹ̀ tí máa ń wọnú ẹ̀ṣà egúngún. Bí apẹ̀ṣà bá ti ń fi ara rẹ̀ hàn, ó ṣe é ṣe kí ó ki oríkì orílẹ̀ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìfira-ẹni-hàn. Bákan náà, kò sí bí apẹ̀ṣà yóó ti ṣèbà àwọn àgbà tí kò níki oríkì wọn. Ohun tí a fi ya ìjúbà àti ìfira-ẹni-hàn sọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bí àkóónú ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni pé kókó kọ̀ọ̀kan wọ̀nyí ṣe pàtàkì ni àyè ìkọ̀ọ̀kan wọn. Èyí túmọ̀ sí pé nígbà tí apẹ̀ṣà bá ń júbà, ìjúbà yẹn ni ó ṣe pàtàkì sí i ní àkókò náà. Bákan náà ni ó jẹ́ pé apẹ̀ṣà kàn ṣe ìmúlò oríkì tí ó kì lásìkò ìṣàfihàn-ara-ẹni ni. Ìsàfihàn gan-an ni ó jẹ ẹ́ lógún jù lọ nígbà náà kì í sẹ oríkì funra rẹ̀. Ní kété tí apẹ̀ṣà bá ti júbà, tí ó sì fi ara rẹ̀ hàn tán, oríkì kíkì ní pẹrẹwu ni ó kàn. Èyí le jẹ́ oríkì orílẹ̀, oríkì ìlú tàbí oríkì bọ̀rọ̀kìní. Àpẹẹrẹ oríkì bọ̀rọ̀kìní kan nìyí nínú ìpẹ̀ṣà, gẹ́gẹ́ bí Ọ̀pádọ̀tun (2002: 53) ṣe fihàn:

Ó wá di wẹ́kú, ó di wẹ́mú
Gẹ́gẹ́ bí òyìnbó wá fẹnu ọkọ̀ tilẹ̀
Mo wá fẹ́ẹ́ lọọlé, Àlàbí ọmọ Ọ̀jẹ́dòkun
Ọmọ Òlóògùn-léégún
Tí ń bẹ lókè Mọ̀lété
Kújẹ́nbọ́lá mọ ẹlẹ́jọ́ awúudu
Ṣebi o gbéégún sí lo gbélù sí
Ọmọ Ọ̀jẹ́dòkun
Lágbàí Ọ̀jẹ̀, jágilégbò ṣoògùn
A nà án lóde ò délé wí
Ó délé, ó tapo sẸ̀lẹ́gbára lẹ́nu
A kọ́rọ̀ gbogbo rò fÈṣù Ọ̀dàrà
Èṣù ní ó gbẹ̀rí ẹ̀ jẹ́

Mọ Kújẹ́nrá
Ọlọ́jẹ̀ẹ́ ọmọ ọnà larè...

Nínú àpẹẹrẹ òkè yìí, apẹ̀ṣà ki Àlàbí ọmọ Ọ̀jẹ́dòkun, ó kì í lọ sí orílẹ̀ rẹ̀. Oríkì orílẹ̀ tí ó kì í sí ni Làgbàyí. Làgbàyí jẹ́ ọ̀kàn pàtàkì nínú àwọn oríkì tí ó jẹ́ mọ́ àwo egúngún. Làgbàyí ni a gbà pé ó máa ń gbẹ́ ère sí orí egúngún. Ó yẹ kí a mẹ́nu bà á ní ìhín pé àwọn apẹ̀sà ni wọn mọ oríkì orílẹ̀ kíkì jùlọ ninú àwọn apohùn Yorùbá. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé àwọn ni wọ́n ń ṣe gbogbo ètòìdí ìsìn àwọn baba ńlá tí wọn jẹ́ olùdásílẹ̀ àwọn orílẹ̀ Yorùbá náà.

#### 4.2.4 Ìwéréùnde

Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣàlàyé nínúìjíròrò wa lórí ìjálá, ìwéréùnde ni gbogbogb àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn tó yàtọ̀ sí ìbà jíjú, ìfira-ẹni-hàn àti oríkì. Eléyìí le jẹ́ ọ̀rọ̀ tó ńlọ ní àwùjọ láti fi dá àwọn òǹwòran lẹ́kọ̀ọ́, ó sìle jẹ́ ọ̀rọ̀ àwàdà, kí àwọn òǹwòran le rẹ́rìn-ín. Èyí máà ń ju ohun ìfirẹ́rìn-ín nìkan lọ ní ọ̀pọ̀ ìgbà torí pé ọ̀nà láti ṣe ìgbékalẹ̀ ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ kí àwọn ènìyàn àwùjọ tó jẹ́ oníṣẹ́ ibi lè yí padà láti ipò àìdára sí ipò dáradára ni ọ̀pọ̀ ìwéréùnde wà fún. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìwéréùnde ìsàlẹ̀ yìí.

1. Lásún: Ọmọ Abílọdẹ́ṣú máa gbọ́ wáàsíì mi,
Wọ̀nrànwọ̀nràn ní òṣùká,
Ọmọ àyá fìlù ọ̀tẹ̀ pè.
Bí ò bá sí ikú
Àdìsá, máa gbọ́ wáàsíìmi;
Ẹni mẹ́ta ni ì bá peraa rẹ̀ lỌ́lọ́run Ọba,
Ẹ wá bi mí, ẹ ní tàni?
Àdìsá: Eléwo ni?
Bó bá ti rí, o làdí ẹ̀ hanni.
Torí àṣípayá lobìnrin ń ṣílẹ̀kùn èèmọ̀.
Lásún: Olówó ì bá pera rẹ̀ lỌ́lọ́run Ọba.
Olóògùn ńkọ́?
Ìbá peraa rẹ̀ lỌ́lọ́run Ọba.
Àlùfáà ńlá, ì bá peraa rẹ̀ lỌ́lọ́run Ọba.
Níjọ́ ikú ó bàá polówó.
Owó wọn ò níí ṣiṣẹ́.
Níjọ́ ikú ó polóògun,
Àgádágodo ni,
Gbètugbètu ni,
Àkáábá ni,
Àbà ni,
Àní gbogbo rẹ̀ ní ó mà wọmi.
Ijọ́ ikú ó pààfáà ńlá
Ẹfúùfù lẹ̀lẹ̀ á máa gbé tákadá ẹ lọ (Ọlájubù, 1972: 112)

2. Bí ẹ bá ń bẹ nílé

Ẹ jẹ́ á máa fura
Onílé apá ọ̀tún ò fojú ire woni
Ìmọ̀ràn ìkà ni tosì ń gbà
Kájáde kájádé ni tọ́kánkán ilé ń wí
Bí ẹ bá ń bẹ nílé
Ẹ jẹ́ á máa fura
Ìran alákàrà o níí fẹ́ kẹ́níkejì ó dín
Bí ẹ bá ń bẹ nílé
Ẹ jẹ́ á máa fura
Ọ̀pọ̀ aláǹgbá ló dakùn délẹ̀
A ò mèyí inú ń run
Ìláyí Aláwùràbí Olódùmarè ò níí jẹ́ a bọ́sọ́wọ́ ayé

Nínú àpẹẹrẹ 1, apẹ̀ṣà kọ́ àwọn olùgbọ́ rẹ̀ lẹ́kọ̀ọ́ nípa ikú àti bí ó ṣe jẹ́ pé kò sí ẹni tí kò níí kú. Ohun tí apẹ̀ṣà fẹ́ fà yọ níbí ni pé kò sí ẹni tí kò níí kù, òògùn ò ran ikú torí náà kí ẹ̀dá ṣe rere. Nínú àpẹẹrẹ 2, apẹ̀ṣà kọ́ àwọn olùgbọ́ rẹ̀ lẹ́kọ̀ọ́ nípa bí ayé ṣe gba ẹlẹ́gẹ́. Apẹ̀ṣà fẹ́ kí àwọn olùgbọ́ rẹ̀ máa ṣọ́ra torí pé ará ilé ẹni ni ó ń ṣeni, ẹ̀bìtì ò pa èèrà. Nígbà mìíràn, ìwéréùnde le jẹ́ ìwúre, èébù, ọ̀rọ̀ dátọ́-n-dánu àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 4.2.5 Ìdágbére

Bí àwọn apẹ̀ṣà bá ti ṣe gbogbo ìwọ̀nyí tán, wọn yóò fẹ́ máa lọ sí ilé. Wọn kò sì níí fẹ́ lọ láì dágbéré fún àwọn olùgbọ́ wọn. Wọ́n le fi ìṣàré dágbéré, wọ́n sì le fi orin dágbéré. Bí ó bá jẹ́ pé ìṣàré ni wọ́n fi bẹ̀rẹ̀ ìdágbére yìí, orin ni máa ń yọrí sí. Èyí túmọ̀ sí pé orin ni wọ́n fí máa ń kádìí ìṣeré wọn nílẹ̀ pátátá. Lára àpẹẹrẹ orin tí àwọn apẹ̀ṣà fi máa ń dágbére ni ìwọ̀nyí.

1. Ẹ jẹ́ ká reléIlé là ń lọỌ̀jẹ̀ kan ò ṣawoṣawo kó gbàgbé ilé

2. Lílé: Àwa ń lọ, ẹ má pá ò dágbére o
   Ègbè: Àwa ń lọ, ẹ má pá ò dágbére o

3. Lílé: Ilé yá, ilé màmà yá ò
   Ká má baà daláṣejù ò
   Ègbè: Ilé yá, ilé màmà yá ò
   Ká má baà daláṣejù ò

Bí àwọn apẹ̀ṣà bá ti ń ṣe èyí ni wọn yóó máa jó, tí wọn yóò sì máa ta òkìtì títí wọn yóó fi kúrò ní ojú agbo ìṣeré.

Ó yẹ kí á tún mẹ́nu bà á, kí a tó ré sórí ohun mìíràn wí pé ìgbésẹ̀ kìn-ín-ní, ìkejì àti ìkarùn-ún kì í sábàá yí padà nínú ìhun àgbékalẹ̀ ẹ̀ṣà egúgún.

Ìgbésẹ̀ kẹta àti ìkẹrin ni apẹ̀ṣà lè máa fi lú ara wọn bí ìṣẹ̀lẹ̀ ojú agbo eré bá ti gbà. Yàtọ̀ sí èyí àwọn apẹ̀ṣà a tún máa kọrin sí ẹ̀ṣà pípè;kò sì sí inú ìgbésẹ̀ tí wọn kò ti lẹ ṣe èyí. Bí apẹ̀ṣà bá dárin kan, gbogbo àwọn tó wà lójú agbo ni yóò jọ gbè é, wọn ó lu bàtá sí i, wọn ó sì jó bàtá. Ó ní irú ìpèdè tí àwọn apẹṣà maá sábáálò láti dá orin àtijó dúró tí wọ́n bá fẹ́ padà sóri ẹ̀ṣà pípè. Wọ́n lè sọ pé,b “Ó tóóóó” tàbí ẹ̀dà fọ́múlà náà míràn bí àpẹẹrẹ.

Ó tó oníbàtá mi
Bá a bá ló tó onílù a sì sinmi
Àìtó onílù a ní í fàjàgbọ̀n
Lẹ́yìn èyí ìlù , ijó àti orin yóò dúró apẹ̀ṣà yóò sì máa bá ẹ̀ṣà pípè nìṣó.

## 4.3 Ìyẹ̀rẹ̀ Ifá

Ìyẹ̀rẹ̀ sísun jẹ́ ohùn ìṣàré àwọn babaláwo tí wọ́n máa ń fi gbé èrò wọn kalẹ̀ lásìkò tí wọ́n bá ń ṣe àṣeyẹ tó jẹ mọ́ Ifá. Ohùn ẹnu àwọn babaláwo, tí wọ́n máa ń gbé kalẹ̀ ní ìlànà ìṣàré, tí wọ́n tún máa ń kọrin ifá sí ni. Wọn a máa lùlùàràn àti agogo sí orin ifá, wọn a sì máa jó sí i. Ìyẹ̀rẹ̀ ifá ni ó ṣe ìkejìnínú àwọn ohùn méjì tí àwọn babaláwo máa ń pè. Tàkọ́kọ́ ni ifá kíkì tí a ti ménu bà ṣaájú. Kíkì ni à ń ki ẹsẹ ifá, ṣùgbọ́n sísun ni à ń sun ìyẹ̀rẹ̀. Àwọn babaláwo a máa fi ohùnìyẹ̀rẹ̀ sísun ki ifá dáadáa. Èyí túmọ̀ sí pé ọ̀kan pàtàkì nínú àkóónú ìyẹ̀rẹ̀ ifá ni ẹsẹ ifá jẹ́. Bátànì lílé àti gbígbè ni a fi ń ṣe àgbékalẹ̀ ìyẹ̀rẹ̀ Ifá. Bí a bá ti ń lé ìyẹ̀rẹ̀, àwọn awo tó wà ní agbo ìṣeré ìyẹ̀rẹ̀ yóó máa fi “Hin-in” tàbí “Hẹn-ẹn”gbè é.

Ògúndèjì (1991) tọ́ka sí i wípé, Ọ̀rúnmìlà ni ó dá ìyẹ̀rẹ̀ sísun sílẹ̀. Bí inú Ọ̀rúnmìlà bá ń dùn, ìyẹ̀rẹ̀ ni yóó fi gbé èrò rẹ̀ jádé. Bí inú rẹ̀ bá sì tún bàjẹ́ bákan náà, ìyẹ̀rẹ̀ ni yóó fi gbé èrò inú rẹ̀ jáde. Ìdí nìyí tí ìyẹ̀rẹ̀ fi di dandan fún àwọn babaláwo. Ṣùgbọ́n Rájí àti Ògúnrántí (2005) ṣàlàyé pé ọmọ bíbí inú Ọ̀rúnmìlà ni Ìyẹ̀rẹ̀. Wọ́n ní ní àsìkò kan, Ọ̀rúnmìlà ṣe àwo lọ. Kí ó tó dé, Ìyẹ̀rẹ̀ ti kú torí pé ara rẹ̀ kò yá, kò sì sí ẹni tó le tọ́jú rẹ̀. Bí Ọ̀rúnmìlà ti dé tó bá òkú Ìyẹ̀rẹ̀, ó bú sẹ̀kún, ó sì ń fi ohùn arò ki ifá. Inú ẹsẹ ifá ìsàlẹ̀ yìí ni ìtàn yìí ti jẹyọ.

Alíbílíbí-Ìjan;
Alìbìlìbì-Ìjan;
Ìjàn-Ìjàn lìbìlìbì
A dífá fún Ìjálá ọmọ ọdẹ.
A dífá fún Rárà tí í ṣọmọ wọn lóde Ọ̀yọ́
A dífá fún Lámọ tí í ṣọmọ wọn lóde Èkìtì.
A dífá fún Ìgè tí í ṣọmọ wọn lódè Òwu.
A dífá fún Ìyẹ̀rẹ̀ tí í ṣọmọ bíbí inú Ọ̀rúnmìlà.
Ìjálá ló kú lọdẹ ń sun bí i tóto.
Rárà ló kú ni wọn ń sun lóde Ọ̀yọ́
Lámọ̀ ló kú ni wọn ń sun lóde Èkìtì

Ìgè ló kú ni wọn ń dá lóde Òwu
Ìyẹ̀rẹ̀ ló kú lawo yà wá sun.
Ègbè:Òkú Ìyẹ̀rẹ̀ ló kú lawo yà wá sun
Òkú Ìyẹ̀rẹ̀ ló kú laawo yà wá sun o ò o

Òkú Ìyẹ̀rẹ̀ ló kú lawo yà wá sun (Rájí àti Ògúnrántí, 2005. v-vi)Àwọn babaláwo a máa sun ìyẹ̀rẹ̀ láti ṣàwòkọ́ṣe Ọ̀rúnmìlà bí ohun tó bà wọ́n nínú jẹ́ bá dé sí wọn.Ohun tí Ògúndèjì sọ àti tiRájí pẹ̀lú Ògúnrántí yìí kò tako ara wọn rararara. Àlàyé ohun tí Ògúndèjì ṣe náà ni Rájí àti ìkejì rẹ̀ fi ìtàn ìwáṣẹ̀ láti inú ifá gbé kalẹ̀.

Lọ́pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni wọ́n máa ń sọ nínú ẹsẹ ifá pé "Ọ̀rúnmìlà fi ìyẹ̀rẹ̀ ṣohùn arò." Èyí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìtàn àwọn onímọ̀ méjì tí a ti tọ́ka sí yìí ti fi hàn pé lótìítọ́ ni pé ohùn arò ni ìyẹ̀rẹ̀ sísun láàrọ̀ ọjọ́. Ṣùgbọ́n lónìía máa ń sùnyẹ̀rẹ̀ lásìkò tí àwọn babaláwo bá péjú pésẹ̀ tí wọ́n ń ṣeọrún ifá, ọdún ifá tàbí tí wọ́n bá ni ṣíṣe kan tó ṣe pàtàkì, tí ó pa àwọn babaláwo pọ̀. Yàtọ̀ sí àsìkò tó bá jẹ́ pé wọ́n níláti dá ifá nínú àwọn àṣeyẹ wọn gbogbo, gbogbo ẹsẹ ifá tí àwọn babaláwo bá ń lò lásìkò àjọyọ̀ wọn, ìyẹ̀rẹ̀ ni wọ́n fi máa ń gbé e kalẹ̀. Bí asùnyẹ̀rẹ̀ kan bá ṣi ẹsẹ ifá kan tí ó fi ń sun ìyẹ̀rẹ̀, kàkà kí àwọn awo ó dá a lóhùn pẹ̀lú "Hin-in" tàbí "Hẹn-ẹn", wọn yóò sọ pé "Báun kọ́" tàbí "Bẹ́ẹ̀ kọ́." Ìyẹ̀rẹ̀ sísun ní ètò tí wọ́n fi máa ń gbé àwọn àkóónúrẹ̀ kalẹ̀.Bí wọ́n bá fẹ́ sùnyẹ̀rẹ̀ ifá, àwọn awo yóò pagbo yíká. Ẹni tí yóó léwájú eré, asùnyẹ̀rẹ̀, yóò bọ́ sí àárín agbo, yóò bẹ̀rẹ̀ ìyẹ̀rẹ̀ sísun, àwọn awo tó wà níkàlẹ̀ yóó sì máa dá a lóhùn. Kì í sàbàá wáyé kí ìdáhùn sí ìyẹ̀rẹ̀ sísun ó jẹ́ "Báun kọ́," nítorí ẹni tí mùṣèmúṣè rẹ̀ kò bá dá lójú kì í bọ́ sójú agbo láti sùnyẹ̀rẹ̀. Bí asùnyẹ̀rẹ̀ kan bá sun ìyẹ̀rẹ̀ lọ títí, ẹlòmìírán yóó gbà á. Agbo ìyẹ̀rẹ̀ sísun ni a lè pè ní àpérò àwọn babaláwo, a sì máa ń mọ bí awo kan ṣe le ki ẹsẹ ifá tó ní irú àpéjọpọ̀ bẹ́ẹ̀. Bí ó bá jẹ́ pé àwọn àgbà awo náà yóó sun ìyẹ̀rẹ̀, àwọn ọmọ awo ni wọ́n kọ́kọ́ máa ń fún ní àǹfààní láti sùnyẹ̀rẹ̀, kí wọ́n lè fi ìmọ̀-ọ́n-ṣe wọn hàn. Ètò ìhun ìgbẹ́kalẹ̀ àkóónú ìyẹ̀rẹ̀ Ifá sísun nìyí ní ṣísẹ̀ntẹ̀lé: kíké sí àwọn babaláwo (ìpèdè ìṣíde ìyẹ̀rẹ̀), ìjúbá, bíbá òǹwòran sọ̀rọ̀, ẹsẹ Ifá àti orin.

### 4.3.1 Kíké sí Àwọn Awo

Níorí pé ìyẹ̀rẹ̀ ifá kì í ṣe àdásun, ó pọn dadan kí asùnyẹ̀rẹ̀ ó ké sí àwọn awo tó wà ní agbo. Èyí ni yóò fi asùnyẹ̀rẹ̀ náà lọ́kàn balẹ̀ pé gbogbo àwọn babaláwo tí ńbẹ níkalẹ̀ ṣetan láti bá a fọwọ́sowọ́-pọ̀. Lẹ́yìn ìkésíni náà àti ìdáhùn gbogbo àwọn olusìn Ọ̀rúnmílà tí ń bẹ níkàlẹ̀ ni ìdánilójú ìfọ̀kànbalẹ̀ yìí tó fẹsẹ̀ múlẹ̀. Ìgbésẹ̀ yìí náà ni ìṣíde ìyẹ̀rẹ̀ sísun. Àpẹẹrẹ nìyí:

1. Awo: Hééééé Eríwopẹ̀ẹ̀
   Eríwo yà, ọmọ Àgbọnmìrègúnún.
   Ègbè: Hin-in

Awo: Bí n bá tí ń wí,
Ẹ ẹ màa jẹ́ mi ní "hìn-in-hìn-in"
Ègbè: Hin-in
Awo: Ẹní tó bá jẹ́ mi ní hìn-in á lógún ẹẹrú,
Ègbè: Hin-in
Awo: Bí mo bá ti ń wí,
Ẹ ẹ màa jẹ́ mi ní "hìn-in-hìn-in"
Ègbè: Hin-in
Awo: Ẹní tó bá jẹ́ mi ní hìn-in á légbèje aya
Ègbè: Hin-in
Awo: Hìn-in lará Olúfẹ̀ ń jẹ́ra wọn
Ègbè: Hin-in lará Olúfẹ̀ ń jẹ́ra wọn o ò o
Hin-in lará Olúfẹ̀ ń jẹ́ra wọn
Hin-in lárá Olúfẹ̀ ń jẹ́ra wọn

2. Awo: Eríwo yà,
Ọmọ Àgbọnmìrègún o o
Ọmọ Awo: Hin-in
(Rájí àti Ògúnrántí, 2005: vii-viii àti 9)

**4.3.2 Ìjúbà**

Ìbà jíjú ṣe pàtàkì nínú ìyẹ̀rẹ̀ sísun bí ó ti rí nínú àwọn ìṣàré yòókù Asùnyẹ̀rẹ̀ gbọ́dọ̀ júbà Ọ̀rúnmìlà àti àwọn àgbààgbà awo tó wà ní agbo eré. Ó gbọ́dọ̀ júbà àwọn awo yòókù náà kí eré rẹ̀ le júṣe fún un. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ yìí:

Lílé: Éééé
Eríwo yà, eríwo fọn
Ìṣòwò ọ̀pẹ̀
Ẹ mà tíẹ̀ ǹlẹ́ ooo
Ègbè: Hin-in
Lílé: Ìṣòwò ọ̀pẹ̀ ẹ mà ṣoko ọba ní hin
Ègbè: Hin-in
Lílé: Alóló omi
Ègbè: Hin-in
Lílé: Alòló omi
Ègbè: Hin-in
Lílé: Àtiwáyé igúnnugún
Ègbè: Hin-in
Lílé: Àtirọ̀run àkàlàmàgbò o
Ègbè: Hin-in
Lílé: Dede ìṣòwò ọ̀pẹ̀
Ẹ jẹ́ á máa júbà ká tó ṣawo
Ègbè: Dede ìṣòwò ọ̀pẹ̀
Ẹ jẹ́ á máa júbà ká tó ṣawo

Dede ìṣòwò ọ̀pẹ̀
Ẹ jẹ́ á máa júbà ká tó ṣawo
Ọ̀rúnmílà oò
Dede ìṣòwò ọ̀pẹ̀
Ẹ jẹ́ á máa júbà ká tó ṣawo
(Rájí àti Ògúnrántí, 2005)

Ìbà Ọ̀rúnmìlà ni asùnyẹ̀rẹ̀ jú níbí. Ó júbà àtiwáyé àti àtirọ̀run náà. Àti àtiwáyé àti àtirọ̀run, Olódùmarè ni wọ́n ń tọ́ka sí. Torí náà, asùnyẹ̀rẹ̀ yìí tún ṣebà fún Olódùmarè náà. Ó gúnlẹ̀ abala yìí pẹ̀lú ìmọ̀ràn fún àwọn awo nínú orin tí ó lé fi kásẹ̀ ìbà rẹ̀ nílẹ̀ pé kì bá dára kí wọ́n máa júbà kí wọ́n ó tó ṣawo.

### 4.3.3 Bíbá Òǹwòran Sọ̀rọ̀

Àwọn asùnyẹ̀rẹ̀ a máa bá àwọn òǹwòran wọn sọ̀rọ̀. Onírúurú ọ̀rọ̀ ni wọ́n sì máa ń bá àwọn òǹwòran sọ. Ó le jẹ́ ọ̀rọ̀ ìkìlọ̀, ó le jẹ́ ìwúre, ìkíni àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ní ìhín ni wọ́n ti máa ń jíṣẹ́ Ọ̀rúnmìlà fún àwọn olùgbọ́ wọn láti fi wọ́n lọ́kàn balẹ̀. Ẹ jẹ́ kí á wo àwọn àpẹẹrẹ yìí:

1. Lílé: Ééééé
Ìṣòwò ọ̀pẹ̀
Ẹ ǹlẹ́ o
Ègbè: Hin-in
Lílé: Ẹni tó dúró ẹ kú ìdúró
Ègbè: Hin-in
Lílé: Ènìyàn tó bẹ̀rẹ̀ ẹ màmà kú ìbẹ̀rẹ̀ o
Ègbè: Hin-in
Lílé: Ẹni tó tòkèèrè wá ẹ kú àgbọ́wáwòran awo
Ègbè: Hin-in (Rájí àti Ògúnrántí, 2005)

2. Lílé: Ó lá à tiẹ̀ níí kú báyìí
Ègbè: Hẹn-ẹn
Lílé: Ó lá a á lówó lọ́wọ́
Ègbè: Hẹn-ẹn
Lílé: Ó lá a á là làà là, o jàre
Ègbè: Hẹn-ẹn

3. Eeèèè, Ifá mọ̀mọ̀ lóun ọ́ gbàyí tá a ṣe e
Eeèèè, Ifá mọ̀mọ̀ lóun ọ́ gbàyí tá a ṣe ò
Ọ̀rúnmìlà o ò
Ifá lóun ọ́ gbàyí tá a ṣe o
Ifá lóun ọ́ gbàyí tá a ṣe o (Ọlátúnjí 1973)
Nínu àpẹẹrẹ 1, asunyẹ̀rẹ̀ kí àwọn olùgbọ́ rẹ̀ tó wáá woran ìṣeré rẹ̀. Nínú 2 ni ó ti jẹ́ṣẹ́ìre ifá fún àwọn olùgbọ́. Orin ni àpẹẹrẹ kẹta yẹn

tí asùnyẹ̀rẹ̀ fi ń fi àwọn òǹwòrran rẹ̀ lọ̀kàn balẹ̀ bí i àpẹẹrẹ 2 wí pé wọn óò bá ojú rere Ọ̀rúnmìlà pàdé.

### 4.3.4 Ẹsẹ Ifá

Ẹsẹ ifá ni ó máa ń kó abala tó pọ̀ jùlọ nínú ìyẹ̀rẹ̀ Ifá. Kò sí bí asùnyẹ̀rẹ̀ yóó ṣe sun ìyẹ̀rẹ̀ tí kò níí ki ifá. Ìdí ni pé, ìyẹ̀rẹ̀ jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì lati mọ bí awọn awo ṣe múná dóko tó nínú ifá kíkì. Awo tí kò bá mọ ẹsẹ ifá dunjú kò níí le sun ìyẹ̀rẹ̀ dé ibìkan tí yóó fi dánu dúró tàbí kí ó máa gbé ẹsẹ ifá fún ara wọn. Nítorí náà, ẹni tí ó bá dá ara rẹ̀ lójú nínú ẹsẹ ifá ni ó le bọ́síwájú àwọn àgbà awo láti sun ìyẹ̀rẹ̀ ifá. Àpẹẹrẹ ẹsẹ ifá kan nìyí tí a fi ìyẹ̀rẹ̀ sísun gbé kalẹ̀:

Awo: Oyún ẹrú o ò o
N ní í dejọ́
Òbò ìwọ̀fà ní í túlùú
Ọ̀rọ̀ ẹ̀ ẹ́ fọlọ́rọ̀ ọ́ lẹ̀
Kó wá àláfohùnfojú-rí í,
Ọmọ Awo: Hẹn-ẹn
Awo: A dífá fún Gbágùúdá
Tí í ṣọmọ Ẹlẹ́fùn-ún-dèrè.
Ọmọ Awo: Hẹn-ẹn
Awo: Kò ṣòjò kò ṣẹ̀ẹ̀rùn,
Gbágùúdá ṣe é rìn lójú omi
Ègbè: Kò ṣòjò kò ṣẹ̀ẹ̀rùn,
Gbágùúdá ṣe é rìn lójú omi o ò o
Kò ṣòjò kò ẹ̀ẹ̀rùn,
Gbágùúdá ṣe é rìn lójú omi
Kò ṣòjò kò ẹ̀ẹ̀rùn,
Gbágùúdá ṣe é rìn lójú omi.
(Rájí àti Ògúnrántí, 2005: 41)

Gẹ́gẹ́ bí á ṣe sọ, bí a bá wo àwọn ètò inú èlé àpẹẹrẹ ìyẹ̀rẹ̀ òkè yẹn, a ó rí i pé àwọn ètò náà wà ní ìbámu pẹ̀lú ètò inú ẹsẹ ifá. Torí náà, ẹsẹ ifá tí a fi sun ìyẹ̀rẹ̀ ifá ni.

### 4.3.5 Orin

Bí asùnyẹ̀rẹ̀ bá sun ìyẹ̀rẹ̀ ifá lọ títí, orin ni ó máa ń fi parí rẹ̀. Àwọn ẹsẹ ifá kan wà tó jẹ́ pé orin ni ó pari wọn. Bí asùnyẹ̀rẹ̀ bá ti sun ún dé ààyè tí ẹsẹ ifá ti já sí orin, dandan ni kí ó lé orin yìí kí àwọn awo sì bá a gbè é. Ẹ jẹ́ jẹ́ kí á wo àwọn orin ìsàlẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹyọ tẹ̀lé ẹsẹ Ifá.

1. Lílé: Iná kú feérú bojú òo òo o
ọ̀gẹ̀dẹ̀ kú fọmọ ẹ̀ rọ́pò
Díá Fágbàànìkàn ṣẹbọ ọmọ

Ègbè: Hẹn-ẹn
Lílé: Èmi nìkan ò le kúnlẹ̀ ńbèdú
Ègbè: Hẹn-ẹn
Lílé: Bọ́mọ bá gbégbáayọ̀
Aya a gbégbá ata
Ègbè: Hẹn-ẹn
Lílé: Ìwọ̀n kàn ni òṣùká bàǹbà tíí fi ràgbàtí òo
Ègbè: Hẹn-ẹn
Orin: Òwíndínwìndìn ire ọmọ jẹ dagbà
Ní Ẹdẹ òo
Òwíndínwìndìn ire ọmọ jẹ dagbà
Ní Ẹdẹ òo

2. Lílé: Ó sú mi òo ò
Ó rẹ̀ mí
Agara dá mi
Pẹnkẹlẹpẹ awoolé Ọ̀rúnmìlà
Ló ṣefá fỌ́rúnmìlà
Ifá óò fẹ̀yìn tì
Yọ́ pẹgbẹ̀rún ènìyàn rán ńṣẹ́
Ègbè: Hẹn-ẹn
Lílé: Ifá jọ́mọ ó pèmí ní baba
Èrò Òpo
Èrò Ọ̀sà
Orin: Ifáà jọ́mọ ó pèmí ní baba òo
Ọ̀rúnmìlà òo ò
Ifá jọ́mọ ó pèmí ní baba òo
Ifá jọ́mọ ó pèmí ní baba (Ọlátúnjí 1973)

Ìwúre ọmọ ni kókó pàtàkì tó súyọ nínú àwọn orin méèjì yìí. Nígbà mìíràn, kokó orin inú ìyẹ̀rẹ̀ le jẹ́ ìfagbára Ifá hàn, ó sì le jẹ́ ìwúre mìíràn yàtọ̀ sí ìwúre ọmọ. Ó le jẹ́ ìwúre owó, ẹmí gígùn àti ìbàlẹ̀ ọkàn. Orin yìí máa ń ní lílé, ó sì máa ń ní ègbè. Ìlù àràn àti agogo ifá ni a máa ń lù sí i. A tilẹ̀ lè rí orin Ifá gẹ́gẹ́ bí irúfẹ́ ewì Ifá mìíràn náà bí Rají àti Ògúnrántí (2004) ti ṣe. Ṣùgbọ́n o bí a ti fi hàn tẹ́lẹ̀ àti bí a ti fi hàn ní ìhín orin ifá a máa jẹyọ nínú ifá kíkì àti ìyẹ̀rẹ̀ sísun náà dáadáa.

## 4.4 Òrìṣà Pípè:Ṣàngó Pípè bí Àpẹẹrẹ

Òrìṣà pípè ni ohùn ìṣàré tí a fi ń ki oríkì àwọn òrìṣà bíi Ṣàngó, Ọya, Ọbàtálá, Yemọja àti Èṣù. Ewì ìjọsìn ni àwọn ewì alohùn yìí, àwọn akóónú wọn a sì máa fi agbára àwọn òrìṣà tí à ń pè hàn ju ohunkóhun mìírràn tí ó tún le wà nínú àkóónú wọn lọ. Nínú àwọn ọ̀wọ́ ewì alohùn yìí, Ṣàngó pípè ni a yàn gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ ní inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Ó yẹ kí á mẹ́nu bà á ní ìhín pé ọ̀tọ̀ ni Ṣàngó tí ó jẹ ọba ní Ọ̀yọ́, ọ̀tọ̀ sì ni Ṣàngó òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀,ọkọ Ọya tí a tún mọ̀ sí Jàkúta. Babayẹmí Ìtíolú ni orúkọ

ọba Ọ̀yọ́ tí a tún ń dà pè ní Ṣàngó. Ọmọ Ọdẹ́dé, tí a mọ̀ sí Ọ̀rànmíyàn sì ni. Ẹlẹ́gùn Ṣàngó ni, alágbára àti akínkanjú jagunjagun sì ni pẹ̀lú. Kò yani lẹ́nu pé gbogbo oríkì Ṣàngó tí ó jẹ́ òrìṣà náà ni wọn fi ń ki ọba yìí nítorí Ẹlẹ́gùn tí ó jẹ́.

Àwọn adóṣù Ṣàngó ni ó máa ń pe Ṣàngó. Àwọn kan a tún máa pe Ṣàngó pípè ní rárà Ṣàngó. Ìyàtọ̀ díẹ̀ wà láàrin rárà Ṣàngó àti Ṣàngó pípè. Nínú Ṣàngó pípè, a kì í ṣe àgbékalẹ̀ oríkì Ṣàngó ní bátànì lílé àti gbígbè gẹ̀gẹ̀ bí a ti máa ń ṣe nínú rárà Ṣàngó. Ìlú Ọ̀yọ́ ni Ṣàngó pípè ti wọ́pọ̀ jù nígbà tí rárà Ṣàngó wọ́pọ̀ ní Ìbàdàn. Àti rárà Ṣàngó, àti Ṣàngó pípè, Ṣàngó kan náà ni wọ́n fi ń kì. A lè sọ pé oríṣi ẹ̀yà Ṣàngó pípè ni rárà Ṣàngó.Àwọn ìgbésẹ̀ tí adóṣù Ṣàngó máa ń tẹ̀lé ní sísẹ̀ntẹ̀lé bí wọ́n bá fẹ́ láti pe Ṣangó ni ìwọ̀nyí; kíké sí Ṣàngó (tàbí ṣiṣe ìbà Ṣàngó), kíki oríkì Ṣàngó, oríkì àwọn ènìyàn lójú agbo (orílẹ̀ tàbí/àti bọ̀rọ̀kìni), pípadà sí oríkì Ṣàngó àti orin ìkádìí.

### 4.4.1 Kíké sí Ṣàngó

Bí àwọn adóṣù bá fẹ́ pe Ṣàngó, pípe àwọn orúkọ ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ tàbí àwọn orúkọ tó fi òrìṣà yìí hàn gẹ́gẹ́ bí alágbára ni wọ́n kọ́kọ́ máa ń pè kíkankíkan bí ẹni pé kí ó dá wọn lóhùn ní ẹsẹ̀kẹsẹ̀. Àpẹẹrẹ bí wọ́n ṣe ń ké sí i nìyí

Lílé: Kábíyèsí ò!
Kábíyèsí ò!
Kábíyèsí ò!
Àképè ọmọ ò ṣé é bora.
Ègbè: Kábíyèsí àgbàlagbà òrìṣà.
Kábíyèsí àgbàlagbà òrìṣà....
(Ọlábímtán, 1988: 7)

Ṣàngó ni adóṣù pè ní Kábíyèsí nínú àyọlò òke yẹn. Ìgbàgbọ́ àwọn olùsìn/adóṣù Ṣàngó ni pé bí àwọn bá pè é báyìí, ẹ̀mí rẹ̀ yóò rọ̀ sí ààrín àwọn. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, kíké sí Ṣàngó yìí a máa já sí ìjúbà tàbí oríkì Ṣàngó bí ó bá ti gùn jù.

### 4.4.2 Kíki Oríkì Ṣàngó

Nígbà tí a bá ti ké sí Ṣàngó tán, oríkì Ṣàngó ló kù tí àwọn adóṣù Ṣàngó máa ń kọ́kọ́ kì ní pẹrẹu. Wọ́n gbà pé bí àwọn kò bá ṣe bẹ́ẹ̀, Ṣàngó le bá àwọn jà torí pé onínúfùfù ni. Nínú abala Ṣàngó pípè yìí ni àwọn adóṣù Ṣàngó tí máa ń kan sáárá sí i, tí wọ́n máa ń kì í ni oríṣìírìṣìí oríkì láti fi bí agbára rẹ̀ ṣe pọ̀ tó hàn. Àwọn oríkì tó banilẹ́rù ni oríkì Ṣàngó, èyí a sì máa fi hàn pé òrìṣà lílé tí ó nílò kí á máa bẹ̀ ẹ́ ni. Abala yìí náà ni ó máa ń pọ̀ jùlọ nínú Ṣàngó pípè. Àpẹẹrẹ oríkì Ṣàngó nìyí:

1. Lílé: Kábíyèsí ò!
Kábíyèsí ò!
Kábíyèsí ò!
Àképè ọmọ ò ṣé é bora

Ègbè: Kábíyèsí àgbàlagbà òrìṣà.
Kábíyèsí àgbàlagbà òrìṣà.
Kábíyèsí, Ajeyín, Akéyín ọmọ ò ṣé é bora.
Kábíyèsí, Arélumọ bí owú o!
Elétí a bojú yẹ̀ri, yẹ̀ri.
Rénpé Oko.
Àlùbó Ọ̀tà.
Èlùbọ́ díẹ̀ ló dànù, ló gbegbèje àmọ̀là.
Àṣáálẹ ní í pojú èké mọ́ ni,
Bó bá pọlọ́rọ̀
A pòfófó ilé,
A pojú taa ló ṣe
Ọ̀rọ̀ Ṣàngó, bí ò bá ṣojú mi ò délé wí
Alárámakà tí í dẹ́rù bojo.
N ni wọ́n ń bọ nílée wa.
Àgbàlagbà bú arúgbó ṣẹnu pómú.
Ṣàngó ni n ó sìn;
Ṣàngó ni n ó sìn;
N ò ṣẹ̀sìn àjòjì.
Jẹ́ kí n rójú sìn ọ́ o!
Baba, má padà lẹ́yìn mi
Ó ń jó gbaa rin. (Ọlábímtán, 1988: 7)

2. Eégún Abiiná
Òòṣà Àlàrí Ọ̀pá
Kọ́dẹ mókè babaà mi
Òmìímì kan
Wọn ò gbọdọ̀ meyín erin
Babaà mi òmììmì
Wọn ò le mòkè
Iṣẹ́ ẹ̀fúùfù lẹ̀lẹ̀
Àrá omi tí í so sókè tọ̀run
Abíiná ń ṣe bí i kó wó bí i kó ya
Bàtà Àkàrí ì jáyé ó tú
Ẹlẹ́gùn ni Babaà mi (Ọ̀pádọ̀tun, 2002: 63)

Ara ìjọ́sìn fún Ṣàngó ni àwọn adóṣù Ṣàngó ka oríkì Ṣàngó sí, torí náà, tọkàntọkàn ni wọ́n fi máa ń ki òrìṣà yìí. Ohun kan tí a kò gbọdọ̀ má peàkíyèsí sí ni wí pé bí àwọn adóṣù bá ti n ki Ṣàngó ní mẹ́sàn-mẹ́wàá ni wọn óò máa pàrọwà sí i pé kí ó má bá wọn jà, bí ó ti hàn nípарí Ṣàngó pípè àkọ́kọ́ yẹn.Àpẹẹrẹ irú àwọn ìpèdè bẹ́ẹ̀ míràn nìyí:

Má bà ń lórí jẹ́
Dákun má forîimi sàsun jẹ
Mọ́ jẹ̀ẹ́ n tẹ́, eyín, wọn ọ̀ tẹ́ lọ́dọ̀ ẹnu
Ọkọ mi májẹ̀ẹ́ ntẹ́, aṣọ funfun ọ̀ tẹ́ lọ̀dọ̀ oìṣà
Òjé ọ̀ tẹ́ lọ́wọ́ ọlọ́bàtálá
Ọmọláńganran ò tẹ́ lọ́dọ̀ Ọya(Oyèbánjí 1972: 23, 24)

### 4.4.3 OríkìÀwọn Ènìyàn Lójú Agbo

Bí àwọn adóṣù Ṣàngó bá ti ki Ṣàngó lọ kì í bọ̀, wọn yóó ki oríkì àwọn ènìyàn tó wà lójú agbo. Wọ́n le ki oríkì àwọn bọ̀rọ̀kìní tó wà ní ojú agbo wọn tàbí kí wọ́n ki àwọn olùgbọ́ wọn sí orílẹ̀, ìlú tàbí ìdílé wọn. Wọ́n sì le ki ara wọn tàbí onílù wọn. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ oríkì bọ̀rọ̀kìníàti ti ìdílé bí ó ṣe jẹyọ nínú Ṣàngó pípè ìsàlẹ̀ yìí:

Àyàn ọmọ Àyánwálé!
Bá a sì ló tó,
Onílù a sì sinmi.
Àyàn ọmọ Adéagbo.
Bàtá onílù ọmọ Àyánwálé.
Aláìníláárí Oníbàtá ò gbaṣọ.
Aláìníláárí Oníbàtá ò gbẹ̀wù.
Aláìníláárí Oníbàtá ò gbaya.
Àrẹ̀mọ Ahéré-ọlá.
Oníbàtá onílù Orò.
Ọmọ lo ó fàyàn lé lọ́wọ́.
Ọmọ náà ní ó gba Ṣàngó lọ́wọ́ èmi.
Mo le rẹrù gbogbo.
N ò lè ru jọ̀lọ̀.
Jọ̀lọ̀ Àfọ̀njá ọmọ Adìkúùkù ṣápẹ́ fÉégún jó.
Ògúlúùtu-pẹ̀ẹ́ nílé ọlọ́rọ̀.
Àfọ́kù ìkòkò tí í rọ́ kẹ́kẹ́-kẹ́kẹ́. (Rájí, àtàwọn yòókù, 2009:70)

Oníbàtá rẹ̀ ni adóṣù tí ó ń pe Ṣàngó nínú àpẹ́ẹrẹ òkè yẹn ń kì. Ó tọ́ka sí baba rẹ̀ tí í ṣe Àyánwálé. Ó tún jẹ́ kí á mọ̀ pé ọmọ Adéagbo ni onílù bàtá náà àti pé òun náà tún ni àrẹ̀mọ Ahéré-ọlá. Ó lè jẹ́ ẹnìkan náà ni ó ni orúkọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí, ìkan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ nínú wọn sì lẹ jẹ́ti babańla rẹ̀ kan tàbí jù bẹ́ẹ̀.Akéwì jẹ́ kí á mọ̀ pé oníbàtá tí ó níláárí ni onílù òun torí pé ó le lu bàtá gba aṣọ àti ìyàwó. Ó wúre fún oníbàtá rẹ̀ pé ọmọ ni yóó jogún iṣẹ́ rẹ̀. Jò sì gbàgbé ara rẹ̀ náà; ó wúre fún ara rẹ̀ pé ọmọ niyóó jogún Ṣàngó òun. Lẹ́yìn èyí ni akéwì ki ara rẹ̀. Ó pe ara rẹ̀ ní "Jọ̀lọ̀ Àfọ̀njá ọmọ Adìkúùkù ṣápẹ́ fÉégún jó", "Ògúlúùtu-pẹ̀ẹ́ nílé ọlọ́rọ̀" àti "Àfọ́kù ìkòkò tí í rọ́ kẹ́kẹ́-kẹ́kẹ́." Gbogbo ìwọ̀nyí jẹ́ oríkì ìdílé àti ti bọ̀rọ̀kìní akéwì.

### 4.4.4 Pípadà sí Oríkì Ṣàngó

Bí àdóṣù Ṣàngó bá ti ki àwọn ènìyàn ní ojú agbo dé ààyè kan, ó di dandan kí ó padà sí orí oríkì Ṣàngó. Bí wọ́n bá fẹ́ ṣe eléyìí, wọ́n máa ń jẹ́kí àwọn olùgbọ́ wọn mọ̀. Nínú gbólóhùn Ṣàngó pípè náà ni wọn yóò ti sọ èyí. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, lára àwọn ìpèdè tàbí fọ́múlà tí sọ pé wọ́n fi máa ń ta àwọn olùgbọ́ wọn lólobó pé àwọn ti fẹ́ pada sórí oríkì Ṣàngó nìyí:

"Ibi a bá roko sí là á fàbọ̀ sí"(Ògúndèjì1991: 91)

Bí àwọn adóṣù Ṣàngó bá ti ń sọ èyí, ajẹ́ pé wọn kò ní í pẹ́ mú ìṣeré náà wá sópin nìyẹn. Kí wọ́n tó mú ìṣeré wọn wá sópin, wọ́n gbọ́dọ̀ tún padà sí oríkì Ṣàngó. Èyí jẹ́ ọ̀kan tó fi ẹ̀rí pé àwọn adóṣù Ṣàngó bẹ̀rù rẹ̀ nìyí. Wọ́n gbà pé bí àwọn kò bá ṣe bẹ́ẹ̀, Ṣàngó le bínú. Èyí tún ń tọ́ka sí i pé oríkì Ṣàngó ló ṣe pàtàkì jùlọ nínú Ṣàngó pípè, òun ni wọn fi ń bẹ̀rẹ̀ òun náà ni wọn sì fi ń parí ere.

### 4.4.5 Orin ìkádìí

Bí àdóṣù bá ti ń pe Ṣàngó lọ ni wọ́n tí máa ń dárin tó fi agbára Ṣàngó hàn. Orín inú Ṣàngó pípè a tún máa ní àkóónù ẹ̀bẹ̀ àti ìkìlọ̀ fún àwọn elétí kunkun sí àṣẹ tàbí agbára òrìṣà Ṣàngó. Èyí yàtọ̀ sí orín ìkádìí, ìwúre àti wíwá ojú rere Ṣàngó ni orin ìkádìí Ṣàngó pípè sábàá máa ń jẹ́. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Lílé: Ká relé e e,
Ọkọ ìyá mi ká relé,
Òjò ò mẹni ọ̀wọ̀ o
Ègbè: Ká relé e e,
Ọkọ ìyá mi ká relé,
Òjò ò mẹni ọ̀wọ̀ o (Rájí, àtàwọn yòókù 2009:74)

Bí àwọn olùsìn Ṣàngó tí a pè ní adóṣù bá tí ń kọrin ni àwọn onílù bàtá yóó máa lu ìlù náà lákọlákọ, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóó máa já bàtá. Àjótàpá ni wọ́n ń jó ijó bàtá. Bí wọ́n ti ń kọ orin kan tán ni wọn yóó máa dá orin ìdágbére mìíràn títí tí wọn yóò fi kúrò ní ojú agbo eré.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Àwọn ìṣàré ajẹmẹ́sìn ni a gbé yẹ̀wò nínú ìpín yìí. A ṣàlàyé nípa àwọn tó ń ṣe wọ́n, àkókò tí wọ́n ń ṣe wọ́n, bí wọ́n ṣe ń ṣe wọ́n, àwọn ohun èlò orin tí wọ́n ń lòpẹ̀lú orin àti ijó ní ojú agbo eré wọn àti àwọn àkóónú wọn. A ṣàlàyé pé gbogbo àwọn ìṣàré tí a gbé yẹ̀wò wọ̀nyí ni oríkì òrìṣà tí wọ́n jẹ mọ́ ti máa ń jẹyọ nínú wọn.

Ohun kan tó yẹ kí á sọ níhìn-ín ni pé ìdí ìsìn àwọn òrìṣà tí ìṣàré ajẹmẹ́sìn kọ̀ọ̀kan jẹ mọ́ ni a kọ́kọ́ mọ̀ wọ́n mọ́. Bí a bá lò wọ́n fún ayẹyẹ idánilárayá kan tàbí òmíràn, eyí kì í ṣe ohun àkọ́kọ́ tí wọ́n wà fún níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Lẹ́yìnọ̀rẹyìn ni irú àmúlò bẹ́ẹ̀ jẹ yọ. Àyẹyẹ tí ó bá sì ní í ṣe pẹ̀lú àwọn olùsìn òrìṣà kọ̀ọ̀kan ni wọ́n ti ń lò wọn nítorí pé àwọn olùsìn òrìṣà nìkan ni wọ́n lè jẹ́ apohùn àti òṣèré. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé oríkì orílẹ̀, tìdílé àti bọ̀rọ̀kìnní lè jẹ yọ nínú gbogbo àwọn ìṣàré ajẹmẹ́sìn síbẹ̀ oríkììbọ tàbí òrìṣà kọ̀ọ̀kan ṣe pàtàkì púpọ̀púpọ̀ nínú ìkọ̀ọ̀kan wọn.Yàtọ̀ sí oríkì Ògún nínú ìjálá, oríkì àwọn akíkanjú ọdẹ, ẹranko, igi àti ẹyẹ igbó náà ṣe pàtàkì nínú ìjálá nítorí pé ó tún jẹ mọ́ṣẹ́ ọdẹ, níwọ̀n ìgbà tí ìjálá tun jẹ́ eré ọdẹ. Nínú ẹ̀ṣà egúngún oríkì orílẹ̀ ni ó ṣe pàtàkì jù lọ. Ìdí ni pé àwọn baba ńla Yorùbá tí à ń fi egúngún ṣèrántí wọn ni olùdásílẹ̀ àwọn orílẹ̀ Yorùbá; àwọn sì ni ìbọ inú ìṣorò àwọn eléégún. Nínú ìyẹ̀rẹ̀ ifá yàtọ̀ sí oríkì Ọ̀rúnmìlà, odù ifá kíkì ni ó ṣe pàtàkì jù lọ. Nínú awo ifá, ìbọ ni wọ́n ka àwọn odù yí náà sí. Nínú Ṣàngó pípè oríkì Ṣàngó ni ó ṣe pàtàkì jùlọ. Bákan náà sì ni ọmọ ṣorí ninú àwọn òrìṣà pípè yòókù; oríkì oríṣà tí ìkọ̀ọ̀kan bá jẹ mọ́ ni yóò ṣe pàtàkì jù lọ nínú ìkọ̀ọ̀kan.

Ó tún yẹ kí á ránra wa létí pé orin ṣe pàtàkì nínú àwọn ìṣàré náà. Bí wọn bá ti ń ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìṣàré náà ni wọn óò máa fi orin lú u. Ní àkókò tí wọ́n bá ń kọrin báyìí ni àwọn olùwòran máa ń ráyè kópa nínú ìṣeré yálà gẹ́gẹ́ bí elégbè orin àti oníjó nítorí bí wọn bá ti lé orin ni ìlù yóò ti sọ tiijó yóò sì tẹ̀lé e. Ìkọ̀ọ̀kan àwọn ìṣàré náà ni ó sì ni irúfẹ̀ ìlù tí wọn máa ń jó sí bi a ti fi hàn nínú ìjíròrò ìpín yìí. Lára àwọn àkóónú tí ó tún pa gbogbo àwọn ewì alohùn yìí pọ̀ ni ìbà jíjú, oríkì orílẹ̀, orin àti ìdágbére.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Jíròrò lórí àkóónú ìjálá mẹ́ta pẹ̀lú àpẹẹrẹ.
2. Jíròrò ìyàtọ̀ tí ń bẹ láàrín àkóónú ìyẹ̀rẹ̀ Ifá sísún àti Ṣàngó pípè.
3. Ṣe àgbéyẹ̀wò ìjẹyọ oríkì nínú àwọn ìṣàré ajẹmẹ́sìn Yorùbá méjì tí ó bá wù ọ́.
4. Kín ni ìbà, kín sì ni ìwúlò rẹ̀ nínú ìgbékalẹ̀ àwọn ìṣàré ajẹmẹ́sìn?
5. Ṣe àlàyé ìmúlò àti ipa orin nínú àwọn ìṣàré ajẹmẹ́sìn.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Àjùwọ̀n, B. 1981. *Ìrèmọ̀jé Eré Ìṣípà Ọdẹ.* University Press Ltd.,Ìbàdàn.

Àlàgbé, S. 2006. *Ìjálá Ògúndáre Fọ́nyánmu: Ìjìnlẹ̀ Èdè Ohùn Ẹnu Yorùbá,* Astra-J Creations,Ògbómọ̀ṣọ́.

Armstrong, R. Ọláyẹmí , V. ; Àwùjọọlá, R. L.; Ògúnyẹmí, W. and Adéníji D. Ìyẹ̀rẹ̀ Ifá: ( transcribers and translators) *The Deep Chants of Ifá at the Ilé Awo Ọ̀ṣogbo, Text in Yorùbá and*

*English* Occasional Publications No. 12, Institute of African studies University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Babalọlá, A. 1966. *The Content and Form of Yorùbá Ìjálá*. Oxford: Clarendon Press.

__________ 1973. *Orin Ọdẹ fún Àṣeyẹ.*Macmillan Nigeria Publishers Ltd.,Lagos.

Ògúndèjì, P.A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. Ìbàdàn: University of Ìbàdàn Centre for External Studies. Ìbàdàn.

____________ 1992. *Yorùbá Drama 1(Eré Oníṣe Yorùbá 1*). Ìbàdàn: University of Ìbàdàn Centre for External Studies, Ìbàdàn.

Olúkòjú, E.O. 1978. "The Place of Chants in Yorùbá Traditional Oral Literature", àpilẹ̀kọ fún oyè Ph.D, Yunifásitì Ìbàdàn.

Oyèbánjí, D. O. The Content and Form of Ṣàngó Pípè, Àpilẹ̀kọ fún Oyè Àkọ́gbà, Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ ìmọ̀ Ẹ̀dá-èdè àti Edè Nàìjíríà (tó ti di ti Áfíríkà báyìí), Yunifásítì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Ọlábímtán, A. 1988. *Àkójọpọ̀ Ewì Àbáláyé àti Ewì Àpilẹ̀kọ,* Paperback Publishers Limited, Ìbàdàn.

Ọlajubu, O. 1972. *Àkójọpọ̀ Iwì Egúngún*. Longman, Nigeran Ltd. Ìkẹjà.

Ọlátúnjí O. O. 1973. "Ìyẹ̀rẹ̀ Ifá: Yorùbá Oracle Chants,"*African Notes*:*Journal of the Institutes of African Studies, Universityof Ibàdàn*Fol. 3, No 2, o. i. 69 – 86.

Ọ̀pádọ̀tun, O. 2002. *Okòó Ewì Alohùn*. Odumatt Press & Publishers, Ọ̀yọ́.

Rájí, S. M. àti Ògúnrántí, J. I. 2004. *Ọ̀*pẹ̀ *Ń Fọ Dídùn 1: Orin Ifá*. Kingson Publishers, Ìbàdàn.

Rájí, S. M. àti Ògúnrántí, J. I. 2005. *Ọ̀*pẹ̀ *Ń Fọ Dídùn 2: Ìyẹ̀rẹ̀ Ifá*. Kingson Publishers.

Rájí, S.M. (Àtàwọn yòókù) 2009. *Ọ̀kan-ò-jọ̀kan Ewì Alohùn Yorùbá*. Ìbàdàn: Alafas Nigeria Company, Ìbàdàn.

Yémiítàn, O. 1979. *Ìjálá Aré Ọdẹ*. Oxford University Press, Ìbàdàn.

# ÌPÍN 4 ÌṢÀRÉ ALÁÌJẸMẸ́SÌN

## AKÓÓNÚ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròńgbà àti Afojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Rárà
4.2 Ẹkún Ìyàwó
4.3 Ọ̀sàré
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ìdí oríṣiríṣi ayẹyẹ tí kò jẹ mọ́ ẹ̀sìn, bí ìnáwó ìgbéyàwó, ìṣílé, ìsọmọlórúkọ àti òkú àgbà ni a ti máa ń ṣalábàápàdé irúfẹ́ àwọn ìṣàré tí a óò gbé yẹ̀wò ní ìhín. Àwọn ìṣàré náà ni rárà, ẹkún ìyàwó àtiọ̀sàré. Gbogbo àwọn ìṣàré wọ̀nyí ni wọn jẹ mọ́ àdúgbò tàbí ẹ̀ka èdè Yorùbá kanpàtó. Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín tí a ṣe gbẹ̀yìn, ọ̀rọ̀ nípa ọ̀gangan ipò àti ìṣeré àwọn ìṣàré náàpẹ̀lú àkóónú wọn ni ó jẹ wá lógun jùlọ níhìn-ín.

## 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí o bá ti ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán, wà á lè ṣàlàyé nípa ìṣàré aláìjẹmẹ́sìn Yorùbá.Ní pàtó; oó ti lè jíròrò nípa àwọn aṣàmúlò ìṣàrénáà, àkókò ìmúlò,àkóónú wọn àti irú ohun èlò orin tí wọ́n ń lò pẹ̀lú wọn.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ní ṣókí, irúfẹ́ ewì alohùn wo ni rárà?
2. Àwọn wo ni aṣàmúlò ọsàré? Àkókò wo ni wọ́n sì máa ń lò ó?
3. Dárúkọ ìṣàré aláìjẹmẹ́sìn ẹ̀ka èdèYorùbá márùn-ún tí o mọ̀.

## 4.0 ÌDÀNÍLẸ̀KỌ̀Ọ́

### 4.1 Rárà

Rárà ni ewì alohùn kan pàtàkì tí a máa ń bá pàdé níbi ayẹyẹ onírúurú láti fi ṣe àyẹ́sí àwọn ènìyàn lójú agbo. Irú ohùn tí wọ́n fi máa ń sun rárà ni a lérò pé ó mú kí wọ́n máa pè é ni rárà. Ìwọ́hùnròrò tó lọ́ra ni a fi máa ń gbé rárà jáde. A máa jọ bí ẹni pé ẹni tí ó ń sun rárà ń sunkún. Gẹ́gẹ́ bí Ọ̀pádọ̀tun (2002) ṣe sọ, ohun rárà ni a fi máa ń pe Èṣù ní ìgbà kan

ṣùgbọ́n ṣá. A kò rí àkóónú oríkì Èṣù nínú rárà mọ́ báyìí láti fi ìdí èyí múlẹ̀ lónìí yìí. Àwọn onímọ̀ kan tún sọ pé nítorí pé igbé rara ni asunrárà máa ń ké bí ó ti ń sun rárà ni wọ́n ṣe ń pèé ní rárà. Ẹnìkan ṣoṣo lè dá sun rárà, bákan náà ni ènìyàn méjì tàbí ju bẹ́ẹ̀ lọ le sun rárà. Bí ọkùnrin ṣe le sun rárà náà ni obìnrin náà le sun rárà. Àwọn asunrárà kan a máa ń káàkiri ibi ìnáwó, wọn ó máa ki àwọn ènìyàn, àwọn ènìyàn náà yóó sì máa ná wọn lówó. ìlù dùndún àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ni wọ́ máa ń lù sí orin inú rárà sísun. Wọn a sì máa lu aro sí i pẹ̀lú. Bí ó bá jẹ́ òṣèré apohùnkan ṣoṣo ni ó ń dá sun rárà, aro ni yóò máa lù sí í. Bí ó bá jẹ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni, tìlù, tiṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ àti aro ni wọ́n máa ń lù sí i.

Oríṣi rárà kan ni èyí tí àwọn apohùn máa ń fi ki àwọn ọba alayé ní ààfin káàkiri ilẹ̀ Yorùbá, pàápàájùlọ ní Ọ̀yọ́. Ọba ni àwọn asunrárà máa ń fi rárà yìí pé. Àwọn asunrárà ní ààfin ni à ń pè ní akígbe ọba. Wọ́n máa ń ki ọba láti yẹ́ ẹ sí. Wọn a tún máa fi rárà wọn yẹ́ àwọn ìjòyè àti ènìyàn pàtàkì pàtàkì tí ó wá bẹ kábíyèsí wò náà sí. Oríṣìí rárà mìíràn tí a máa ń bá pàdé láàfin Ọ̀yọ́ ni yùngbà kíkùn. Èyí jẹ́ rárà tí àwọn ayaba Aláàfin máa ń kùn sí igbá títí. Láti tí igbá, àwọn ayaba yóó gbé odó kalẹ̀, wọn yóò pọn omi sí inú rẹ̀, wọn yóó da igbá pàkátà bò ó, wọn yóó máa kun yùngbà, wọn yóó sì máa fi ọwọ́ tí igbá náà. Ìyẹn ni pé wọn óò máa fi ọwọ́ wọn lu igbá pàkàtá tí wọ́n da ojú rẹ̀ dé omi ínú odó tí wọ́n gbé kalẹ̀ náà. Orí ìkúnlẹ̀ ni wọ́n tí máa ń tígbá láti fi ṣàpọ́nléAláàfin. Yùngbà àti igbá títí yìí ni àwọn ayaba ní ààfin Ọ̀yọ́ máa ń fi kí ọba káàárọ̀ bí ó bá ti jí láyé àtijọ́. Yùngbà kíkùn ní orin nínú dáadáa. Oríkì àti àpọ́nlé aláàfin ni ó máa ń jẹ́ àkóónú yùngbà. Àwọn ayaba a tún máa lo àǹfààní yùngbà kíkùn yìí láti sọ ẹ̀dùn ọkàn wọn fún kábíyèsí torí pé wọn kò le pa guuru bi aláṣẹ èkejì òrìṣà ní ọ̀rọ̀ láìjẹ́ pé wọ́n kọ́kọ́ kì í, wọ́n sì kọ́kọ́ kí i. Ohun tí ó yẹ kí á tún mẹ́nu bà ni pé, kò pọn danadan kí wọ́n tígbá sí yùngbà. Wọ́n le kun yùngbà láì tígbá. Kì sìí ṣe pé ààfin Aláàfin nìkan ni a ti le rí yùngbà, a le rí yùngbà kíkùn náà ní àgbàlá àwọn ìjòyè pàtàkì bíi Baba Ìyàjì, Baṣọ̀run àti Alápìn-ínni. Àwọn àbùdá pàtàkì tí ó ya yùngbà kúrò lára àwọn rárà ìyókù ni pé, bátànì lílé àti ègbè ni a fi ń kun yùngbà àti pé ó ní ohun èlò orin tirẹ̀ tí kò papọ̀ mọ́ àwọn rárà yòókù.

Rárà ìyàwó niorúkọ mìíràn fún ẹkún ìyàwó, pàápàá ní àgbègbè Ọ̀ṣun àti Odò-ọ̀tìn. Bákan náà ni wọn a sì tún máa pe òkú pípè tàbí ògbérè ní rárà òkú.Èyí ni àwọn obìnrin ilé fi máa ń ṣe orò ìdágbére ìkẹyìn fún àgbà ilé; ìṣọkùnrin, ìṣobìnrin tí ó papòdà. A tilẹ̀ lè sọ pé bí ìrèmọ̀jé ti jẹ́ sí ìjálá náà ni ògbérè/ òkú pípè jẹ́ sí rárà. [wo Àjùwọ̀n,1989 fún àlàyé kíkún àti àpẹẹrẹ lórí èyí]. Ó yẹ kí a kíyèsí wí pé ògbérè náà ni a ṣo pé wọn ń pe iwì tàbí ẹ̀ṣà egúngún ní ààrín àwọn Ẹ̀gbá. Ní ààrí àwọn Ọyọ́ ni wọ́n ti ń pe òkú pípè ní ògbérè bí Àjùwọ̀n (1989)ti là á yé wa.Ohùn bíi ti rárà tí a fi ń ki Ṣàngó ni a lérò pé ómú kí wọ́n tún máa pe òun náà ni rárà Ṣàngó ní Ìbàdàn. Ṣùgbọ́n ṣá, ìṣàré ajẹmáyẹyẹ ni ráarà, ògbérè àti ẹkún ìyàwó nígbà tí rárà Ṣàngó jẹ́ ìṣàré ajẹmẹ́sìn, bí àlàyé wa ìṣaájúti fi hàn.

Gbogbo oríkì tí a máa ń lò láti fi ki ènìyàn ni ólè jẹyọ ninú rárà sísun. Àti oríkì orílẹ̀, àti ti ìlú tàbí ìdílé. Ṣùgbọ́n oríkì bọ̀rọ̀kìní ni àkóónú rárà tí ó gbajúmọ̀ jùlọ torí pé nípasẹ̀ kíki oríkì bọ̀rọ̀kìnní ni asunrárà ṣe le rí tọwọ́ àwọn ènìyàn gbà lójú agbo. Gbogbo irúfẹ́ oríkì tí a fi ń ki ènìyàn yòókù ni ósì lè fara hàn níbi tí wọn ti ń ki oríkì bọ̀rọ̀kìnní. Àpẹẹrẹ oríkì bọ̀rọ̀kìní nínú ràrà nì àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Olówóo Wúràọlá, oníbejì ọmọ
Aṣeéperí baba Láwúwo
Nílé ni, lóde ni, ọkọ mi ò bàjẹ́ nínú ẹgbẹ́ ìgbìmọ̀
Lóógun lékòó, ọ̀rẹ́ agbààgbà ìlú
Gbogbo ohun tólówó mi bá ṣe náà ní lápẹẹrẹ
Àṣée-lówó mi o
Àjàgbé ọmọ
Ọmọ Òyènínhún tí í jí ṣe bí ìyàwó
Ọmọ Oyinlọlá Wéríkanbúkà ni baba ọkọ̀ọ̀ mi
Kò ṣẹsẹ̀ ọlà gbé ni baba Láwúwo... (Ọ̀pàdọ̀tun, 2002: 33)

Oríkì bọ̀rọ̀kìnní ni àkóónú rárà òkè yìí. Ọkọ Wúràọlá ni asùnrárà kì, ìdí nìyí tí ó fi pè é ni olówó rẹ̀. Asunràrà fi ọmọ ki í, ó fi ẹgbẹ́ rẹ̀ kì í, ó fi bí ó ṣe gbajúmọ̀ láàárín ìlú tó kì í, ó dárúkọ ìyá rẹ̀, ó jẹ́ ká mọ̀ pé ọmọ Oyinlọlá Wéríkanbúkà ni ẹni tí òun ń kì. Àwọn Mùsùlùmí tí wọ́n ń máa ń wé láwàní bàǹbà ni wọn ń pè ní wéríkanbúkà. Lótìítọ́, èdè àbùkù ni bí a bá pe ènìyàn ní wéríkanbúkà. Ṣùgbọ́n èébú tàbí àbùkù a máa dẹwà nínú oríkì.Ìdí nìyí ti onírárà náà fi lo àbùdá ìtàbùkù náà láti ṣàpọ́nlé ẹni tí ó ń kì.

Orin a tún máa jẹ́ yọ nínú rárà sísun. Bí asunrárà bá ti ń ki ènìyàn ni yóó máa dárin tó bá oríkì rẹ̀ mu. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.
Adébọsìn ọkọ Jẹ́nrọ̀lá.
Kọ̀léoṣó fọtí èèbó bà mí jẹ́,
Ó filé ọtí hàn mí.
Ilé ọlá ò ní wó ọkọ Látúndùn.

Orin – Lílé: Kọ̀léoṣo rọra kó o má ba à ṣubú.
Ègbè: Ṣìgìdì rọra kó o má baà ṣubú.(Rájí, àtàwọn yòókù,2009: 94)

Asunrárà ki Kọ̀léoṣó nínú àpẹẹrẹ rárà òkè yẹn, ó jẹ́ ká mọ̀ bó ṣe máa ń fọtí ṣàlejò tó, lẹ̀yìn èyí ló wúre fún un. Orinìdáninímọ̀ràn ni ìlà méjì tó gbẹ̀yìn àyọlò yẹn. Asunrárà gba Kọ̀léoṣó ní ìmọ̀ràn pé kí ó rọra kí ó má baà ṣùbú. Ó sì pè é ní ṣìgìdì nínú orin tí ó fi parí rárà rẹ̀ náà. Àkàwé ni ó fi èyí ṣe. Ṣìgìdì ni ère tí á fi amọ̀ mọ, tí òwe Yòrùbá kan sọ nípa rẹ̀ pé bí ó bá fẹ́ ṣeré ẹ̀tẹ́, a ni kí wọn ó jẹ́ kí òun bọ́ sódò lọ wẹ̀. Bẹ́ẹ̀ sì ni bí ṣìgìdì bá bọ́ sódò lọ wẹ̀, tapátitan rẹ̀ ni yóó re.[Kí akẹ́kọ̀ọ́ wá ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ rárà s sí i fúnra rẹ̀]

## 4.2.0 Ẹkún Ìyàwó

Bí ati sọ ṣaájú, rárà ìyàwó ni àwọn Yorùbá agbègbè Ọ̀ṣun àti Odò-ọ̀tìn ń pè ẹkún ìyàwó. Láàárín àwọn ẹ̀yà Yorùbá Ọ̀yọ́ àti àwọn agbègbè rẹ̀ ni ẹkún ìyàwó tí wọ́pọ̀ jùlọ. Bí a bá tọ́ka sí ẹkùn Yorùbá Ọ̀yọ́, àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí a ní lọ́kan ni àwọn ìlú bí Ọ̀yọ́, Ìlọrin, Ìbàdàn, Ògbómọ̀ṣọ́, Ṣakí, Ìṣẹ́yìn àti àwọn ìlú tó wà ní Òkè-Ògùn àti Ìbàràpá. Lára àwọn ẹkùn Yorùbá Ọ̀yọ́ ni àwọn ìlú bí Ìwó, Ẹdẹ, Òṣogbo, Ìkirè àti àwọn ìlú mìíràn tí wọn ń sọ ẹka èdè Ọ̀yọ́ ní ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun lónìí. Nígbà tí ọmọbìnrìn bá tó láti lọ sí ilé ọkọ, àwọn òbí rẹ̀ yóò dájọ́ ìyàwó sọ́nà. Ìyàwó ṣíṣe ní ìgbà àtijọ́ kì í ṣe àdáṣe bí ti ayé òde òní. Torí náà, àjùmọ̀ṣegbogbo mọ̀lẹ́bi lápọátùn-ún lápásìnìgbéyàwó. Bí àkókò láti sin àwọn ọmọge tí ó tó ilé ọkọ ọ́ lọ bá tó, ọmọge tí òǹkà wọn tó márùn-ún mẹ́fà le lọ sí ilé ọkọ ní ọjọ́ kan ṣoṣo ní àgboolé kan náà, ní ayé àtijọ.

Nígbà tí àkókò láti lọ sí ilé ọkọ bá tó, ní kùtùkùtù òwúrọ̀ ọjọ́ ìgbéyàwó ni àwọn ọmọge tí ó fẹ́ lọ sí ilé ọkọ yóó ti bọ́ sí ìgboro, tí wọn yóó máa ya ojúlé ẹbí àti ará wọn kirí láti dágbére fún wọn pé àwọn ń lọ sí ilé ọkọ. Ọ̀dọ̀ báálé ilé wọn ni ìyàwó gbọ́dọ̀ ti bẹ̀rẹ̀ìdágbére náà. Bí ó ṣe ń ti ojúlé kan bọ́ sí òmíràn ni yóó máa sun ẹkún ìyàwó láti fi dágbére fún ẹbí àti láti fi dárò pé àsìkò ti tó fún òun láti gba ilé ọkọ lọ. Ewì arò tí àwọn ìyàwó máa ń ké káàkiri láti fi dágbére yìí ni a mọ̀ sí ẹkún ìyàwó. Àwọn ẹbí ará náà yóó ti múra ìyàwó sílẹ̀, wọ́n yóó máa fún un ní ẹ̀bùn oríṣìíríṣìí, wọn yóó sì máa wúre fún un.

Kì í ṣe ẹlẹ́kún ìyàwó nìkan ní í máa ń dá jáde, àwọn ọ̀rẹ́ wọn a máa tẹ̀lé wọn àti àwọn obìnrin ilé wọn. Àwọn ẹlẹ́gbẹ́ ìyàwó yìí a máa ṣe kóríyá fún ìyàwó nípa bíbá a kọ orin ìyàwó ní òde ẹkún ìyàwó. Ìlù dùndún ni wọ́n sì máa ń sábàá lù sí orin wọn.Ó ṣe é ṣe kí àwọn ẹlẹ́kún ìyàwó pàdé ẹgbẹ́ ẹlẹ́kún ìyàwó mìíràn ní òde. Bí èyí bá wáyé, àwọn ẹlẹ́kún ìyàwó méjèèjì le tahùn sí ara wọn láti mọ ẹni tó ní ìmọ̀-ọ́n-ṣe jù nínú ẹkún ìyàwó sísun nínú àwọn méjèèjí. Bí ẹgbẹ́ ẹlẹ́kún ìyàwó kan bá borí èkèjì, ìtìjú ní ó máa ń jẹ́ fún ẹni tí a borí rẹ̀. Òwe tí èyí ń pa ni pé ìyàwó tí a borí rẹ̀ kó gbọ́ ẹ̀kọ́ tó nǹkan. Bí ó bá jẹ́ ọmọ ti ó gbọ́ ẹ̀kọ́, tó sì farabalẹ̀ kọ́ ẹkún ìyàwó sísun láti ilé wá, kò yẹ kí ẹgbẹ́ rẹ̀ jèrè ọ̀rọ̀ ní ara rẹ̀.

Bí ìyàwó bá ti ku bí oṣù mẹ́fà ni ọmọge tí yóò ṣe ìyàwó yóó ti máa kọ́ ẹkún ìyàwó ní ọ̀dọ̀ àwọn ìyàwó ilé wọn. Ohun tí wọ́n máa kọ́ ọ nínú ẹkún ìyàwó pọ̀ díẹ̀. Wọn ó kọ́ ọ ní ìwéhùn àti ìwọ́hùn ẹkún ìyàwó, wọn ó kọ́ ọ ní oríkì orílẹ̀ àti oríkì bọ̀rọ̀kìní, wọn máa kọ́ ọ ní ìwúre, ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín àti àwọn ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ míràn pẹ̀lú oríṣìíríṣìí orin tó jẹ mọ́ àkóónú ẹkún ìyáwó kọ̀ọ̀kan tí wọ́n ń kọ́ ọ. Nígbà mìíràn, ìyàwó ojú ọ̀nà nílò láti jẹ òògùn ìsọ̀yè kí ó le rántí ohun tí wọ́n ti kọ́ ọ. Ohun ìyàngaàn ni ẹkún ìyàwó. Àsìkò yìí ni ìyàwó máa ń fi bí ó ṣe jẹ́ ọmọ rere fún àwọn òbí rẹ̀ yangàn; bí kò sọ ogo obìnrin rẹ̀ nù ṣaájú ìgbeyàwó, tí kò sì dójú ti

gbogbo ẹbí. Gbogbo ìwọ̀nyí ni yóò máa sọ nínú ẹkún ìyàwó tí ó ń sun láti fi mú orí àwọn olùgbọ́ rẹ̀ wú, tí àwọn náà óò sì máa fún un ní oríṣiríṣi ẹ̀bùn láti ṣe kóríyá fún un, tí wọn óò tún máa súre fún pé ilé ọkọ tí ó ń lọ yóò san án. Ọ̀dọ́mọbìnrìn tó bá ti ba ara rẹ̀ jẹ́ kò níí le wẹ̀ yán kàn-ìn-kàn nínú ẹkún ìyàwó sísun yìí. Ẹkún ìyàwó irú wọn kì í lóòrìn. Kò níí pẹ́ lóde tí yóó fi padà wálé kí àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ má baà fi bú u.

Bí ìyàwó bá ti délé ẹbí, tí ó yalé ará darí, yóò padà sí ilé láti gba irè bàbá àti ìyá rẹ̀ kí ó tó máa lọ ilé ọkọ rẹ̀ ní àṣàlẹ́. Yóó dúpẹ́ lọ́wọ́ ìyá àti bàbá rẹ̀, wọn yóò sì súre ilé ọkọ fún un. Àpẹẹrẹ ẹkún ìyàwó nìyí:

Àtìjẹjọ mi rèé, baba tí mo ní o
Wọn bú mi lóde, n ò bú wọn dí i
Wọn ṣẹ̀ mí níjà, n ò jà
Èmi a fìjà sínú pète ẹ̀rin
Mo gbálápẹpẹ lójú
Èmi mọ̀mọ̀ rójú oníjà
N ò tọ́ ọ
Ikú ló tóni yà, tí ò yani
Àrùn ló tóni yà, tí ò yànìyàn
Ọmọ bíbí inú wọ́nwọ̀nyí
Òun ló tóni yà tó sì yani... (Ọ̀pàdọ̀tun, 2002: 16; 2005: 36)

Ìfáárà ni èyí jẹ́ sínú ẹkún ìyàwó. Ọmọge tó ńlọ ilé ọkọ náà ń fi hàn nínú ẹkún ìyàwó tí ósun yìí pé òun ti gbẹ̀kọ́ àwọn òbí òun, òun kì í jà, kì í fa wàhálà àti pé àsìkò tó ti òun óò kó kúrò nílé baba òun lọ sílé ọkọ nítorí òwò ọmọ. Ìyàwó yóò máakọ́minú lórí ilé ọkọ tó ń lọ,
A dógúnjọ́, a dọ́gbọ̀njọ́, ọjọ́ pé
À bẹ́ẹ̀ gbọ́, ọjọ́ ọ̀hún kọ̀la ò
Omínú ń kọ mí ò ṣe tọ̀bẹ
Ẹ̀rù ń bà mí, mo ní kò ṣe tìjà
Ẹ̀rù òkè yìí mà ń bà mí o
Ará òkè yìí, ẹ má lẹ̀ mí lóòka...
(Ọ̀pàdọ̀tun;2002:16-17;2005:36-37)
Ìyàwó máa dágbére ilé ọkọ fún àwọn òbí rẹ̀. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ yìí:
Ibi ó welégédé ní í so dé
Ibi ó wolúfà ní í fàrè
Ibi ó wu baba ọmọ níí ránmọ lọ
Ibi ẹ rán mi ni mo ń rè yìí, ìyá tí mo ní
Ẹ má jẹ́ ó hun mí, màmá mi o(Ọ̀pàdọ̀tun, 2002:19 àti 2005: 100)

Ẹlẹ́kún ìyàwó fi yé wa nínú ẹkún ìyàwó rẹ̀ òkè yí pé àwọn òbí òun ló ni òun, torí náà ibi tí wọ́n rán òun ni òun ń lọ. Ṣé àwọn òbí ni í máa fọmọ fọ́kọ láyé àtijọ́. Ìdágbére fún àwọn òbí rẹ̀ ni gbogbo ìwọ̀nyí.

Oríkì orílẹ̀ ṣe pàtàkì nínú ẹkún ìyàwó. Ìyàwó yóó ki baba rẹ̀, ìyá rẹ̀, ọkọ rẹ̀, àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ àti àwọn ẹbí àti ojúlùmọ̀ tó sun ẹkún ìyàwó lọ sí ọ̀dọ̀ wọn. Ẹ jẹ́ kí á wo bí élẹ́kún ìyàwó kan ṣe ki ẹ̀gbọ́n rẹ̀:
Ọpẹ́lọpẹ́ ká fẹni ṣẹni,
Ọpẹ́lọpẹ́ ká fèèyàn ṣèèyàn,
Ẹ̀gbọ́n tí mo ní, Àlàgbé Ojúbánirẹ́,
Ojúbánirẹ́ ò dékùn ẹni.
Ṣàṣà ènìyàn ní í fẹ́ni lẹ́yìn ba ò sí nílé,
Ṣebí tàjá-tẹran ní í fẹ́ni lójú ẹni.(Ọlábímtán, 1988:93)
Ojúbánirẹ́ tí ẹlẹ́kún ìyàwó fi ki ẹ̀gbọ́n rẹ̀ yìí jẹ́ ara oríkì Ìmọ̀dú ẹlẹ́rìn.Kì í ṣe pé ó kàn ki oríkì ẹ̀gbọ́n rẹ̀, Àlàgbé, ninú àyọ̀lò yìí lásán, ohun pàtàkì tí ó fi kì í mọ́ orílẹ̀ rẹ̀ náà bí ó ti ṣe yìí ni láti fi ẹ̀mí ìmoore hàn fún àdúrótì tí ẹ̀gbọ́n rẹ̀ náà ṣe fún un títí ó fi di ẹni ara rẹ̀.

Oríṣiríṣi àkíyèsí nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń ṣẹ̀ ni ẹlẹ́kún ìyàwó yóò máa mẹ́nu bà, tí ó sì lè máa fi dá àpárá. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹàwọn àpẹẹrẹ méjì, tó gbajúgbajà yìí:

1. Lójú alájá, ó dàbíi kílẹ̀ ó dẹ̀kọ
Lójú amọ̀kòkò ó dàbíi kílẹ̀ ó damọ̀
Lójú àwọn bọ́ńsì òkè ọ̀hún, ó dàbíi kí ń mọ́ mọ̀ tí ì lọ
2. Mo delé ọkọ,
Ọkọ fi ṣílè kan lẹ̀ mí lórí.
Mo déta àlè,
Àlè fi pọ́n-ùn kan lẹ̀ mí lórí
Ẹ bá mi kọ́kọ́ pó kú ìnáwó,
Ẹ bá mi kálè pó kú àṣedànù
Àṣedànù ṣá lowó àlè jẹ́.
Èmi Àkànkẹ́!
Ọmọ ni ó ṣalátìlẹ́yìn mi.
Ire lónìí, orí mi àfire.(Rájí, àtàwọn yòókù, 2009: 103-104)

Nínú àpẹẹrẹ 1, àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin àdúgbò tí wọn ti jọ máa ń bára wọn tage, ni ó pè ní "bọ́ńsì" (*boys*), ó ń fi bí àwàdà bí ẹ̀fẹ̀ dágbére fún wọn lọ́nà ẹ̀rọ. Nínú àpẹẹrẹ 2, bóyá ìkan lárá irú àwọn ọ̀rẹ́kùnrin bẹ́ẹ̀ tí ó tún wa ná an lówó lọ́jọ́ yẹn ni ó pè ní àlè tí ó sì ń fi dá apárá nínú àyọlò náà. Ó fi kún ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé, bí ó ṣe le wù kí àwọn ọkùnrin náà fẹ́ fi owó fa ojú òun mọ́ra tó, àṣedànù lásán ni wọ́n ń ṣe. Ní ìparí àyọlò náà, ó wúre ọmọ fún ara rẹ̀. Èyí fi hàn pé ọ̀kan pàtàkì nínú àkóónú ẹkún ìyàwó ni ìwúre. Báyìí ni ẹlẹ́kún ìyàwó yóó
gbìre tí yóó sì gba ilé ọkọ rẹ̀ lọ.Ohun kan tí àwọn ẹlẹ́kún ìyàwó tún máa ń mẹ́nu bà tí akò gbọdọ̀ má sọ ni ìpayà àì mọ bí ile ọkọ yó ti rí fún un, pàápàá nípa irú ìyáálé àti iyakọ tí yóó bá pàdé nílé ọkọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

A ì í gbè é deégún,
A ì í gbè édòòṣà

Èmí wáá dìyàwó
Èmí wáá dagbẹ́yìn-adìẹ!...
Ng ò ti wa ṣé?
Ọ̀nà wo ni n ó mà tiẹ̀ rìn?
À á tí ṣe táìí fi í tẹ́?
À á tí ṣe é táìí fí í ṣìṣe
Tá a bá délé ọkọ báyìí?
Mo láàá ti í ṣe étàì fí í ṣìṣe?
Tááá fi í múwà àwọn àgbà hù.
Tíwọ́n fíí ránni níṣẹ́ àwọn àgbà.
Táìí fií mú tèwe jẹ́?
Nítorí pé èébú mẹ́ta ni wọ́nọ́n búni nílé ọkọ-
Bóo gúnyán, wọ́n a ló ni kókó.
Bóo gunlùbọ́, wọn a léètà dà sí i.
Bóo rokà, wọn a ló mà tiẹ̀ rọ̀.
Kàkà ki wọn pèọ́, kí wọ́n báọ wí,
Wọn a ní nítorí pé ò ìí ṣọmọ̀àwọn ni
Wọn a pe baálé ilé,…(Ládélé àti Fáníyì 1979: 11 – 12 )
[Ka Ládélé àti Fáníyì (1979) àti Ọ̀pádọ̀tun (2002 àti 2005) láti ṣàwárí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ sí i]

## 4.3 Ọ̀sàré

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Ọ̀pádọ̀tun (2002), bí rárà ṣe rí sí àwọn Yorùbá Ọ̀yọ́, tí ègè rí láàrin àwọn Ẹ̀gbá ni ọ̀sàré rí láarin àwọn Ifẹ̀. Ohun tí èyí ń tọ́ka sí ni pé, níbi oríṣiríṣi ayẹyẹ ni àwọn Ifẹ̀ ti máa ń ré ọ̀sàré.Níbi onírúurú ayẹyẹ ni a ti le ré ọ̀sàré. A le ré e níbi ayẹyẹ ìkómọ, ìṣílé, òkú àgbà, ìwúyè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ríré ọ̀sàré ni fífi ẹ̀ka èdè Yorùbá Ifẹ̀ ki oríkì bọ̀rọ̀kìnní àti oríkì orílẹ̀ fún àyẹ́sí. Àwọn obìnrin ilé ọlá ní Ilé Ifẹ̀ ni wọ́n máa ń ki àwọn ọkọ wọn pẹ̀lú ìwéhùn ọ̀sàré láti fi ṣe àpọ́nlé wọn, wọ́n máa ń kọrin sí ọ̀sàré bíi ti àwọnì ìṣàré yòókù. Lọ́pọ̀ ìgbà ló jẹ́ pé bátànì lílé àti gbígbè ni wọ́n máa ń fi ń ré ọ̀sàré. Wọn a sì máa patẹ́ sí i. Yàtọ̀ sí oríkì, ìbà, ìwúre, oríṣiríṣi àkíyèsí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, àwàdà, ìwúre àti orin a máa jẹyọ nínú ọ̀sàré. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ̀ìjúbà,

Hé é é!
Háa sìn.
E è è, a gbéré ria dé,
A foríbalẹ̀ hún ìhan baba ńlá ria.
A júbà Ọba Èdùmọ̀rè.
A mí pe Ọ̀ranfẹ̀
O nílé iná ko lá bá a pé.
Gbogbo ìhin irúmọ̀lẹ̀ la mọ̀ yíràá kò o.
Èmi ọmọ Arájońwò kórà mẹ.
Mo ṣe kí ìhan ẹlẹ́gbẹ́ mi,
Àṣeyè la máa ṣe ò.

Nítorí àṣeyè lalákàn ṣepo... (Ọlábímtán, 1988:84)

Ìjúbà ni ìwọ̀nyí nínú ọ̀sàré. Ọ̀ṣèré yìí júbà Olódùmarè, ó júba Ọ̀ranfẹ̀ àti gbogbo àwọn ìrúnmọlẹ̀. Lẹ́yìn èyí ló fi ara rẹ̀ hàn. Ó kí àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀, ó sì wúre àṣeyọrí fún ẹgbẹ́ wọn. Bí a bá kíyè sí àyọlò yìí, ìfira-ẹni-hàn àti ìwúre wà lára kókó tó jẹyọ nínú ọ̀ṣàré náà. Ó hàn gbangba pé ìṣíde ìṣeré ni àyọlò náà wà fún.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ, oríkì ni kókó pàtàkì tó máa ń jẹyọ nínú ọ̀sàré jùlọ. Èyí le jẹ́ oríkì orílẹ̀ tàbí oríkì bọ̀rọ̀kìnní. Àpẹẹrẹ oríkì bọ̀rọ̀kìnní kan nìyí.

Ṣebí mo rí Fọláṣadé yèyé mi Fọlárìn ooo
Ẹyẹ amùjò
Ebi mọ̀ ń perin
Aya ń fọ̀kòkò ó nù
Ẹyẹ amùjò
Dedi tòun tẹ̀jẹ̀ yóróyòró o
Ẹyẹ amùjò
Olówó Ifẹ̀
Ló bọ́mọ mi Oríjọkẹ́ yìí o
Ẹyẹ amùjò
Ọmọ o mise ralapin rèé o
Ó ṣe bẹ́ẹ̀ jówọ́de Òkèrèwè
Ẹyẹ amùjò (Ọ̀pádọ̀tun, 2002: 46)

Oríkì Fọláṣadé Fọlárin ni ọlọ́sàré kì níbí. O jẹ́ ká mọ̀ pé ọmọ Ifẹ̀ ni àti pé ọmọ ènìyàn pàtàkì ni ní Ifẹ̀. [Kí akẹ́kọ̀ọ́ ka Ọlábímtán (1988) àti Ọ̀pàdọ̀tun (2002 àti 2005) tàbí àwọn ìwé mìíràn tó ṣàlàyé kíkún nípa ọ̀sàré fún àpẹẹrẹ síwájú sí i.]

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí a jíròrò lórí ìṣàré aláìjẹmẹ́sìn mẹ́ta wọ̀nyí: rárà, ẹkún ìyàwó àti ọ̀sàré. A jíròrò nípa àwọnaṣàmúlò wọn,àkókò tí wọ́n máa ń lò wọ́n àti àwọn àkóónú wọn.

Gẹ́gẹ́ bí i ti àwọn ìsàré ajẹmẹ́sìn, a rí i wí pé oríkì ṣe pàtàkì nínú àwọn ìṣàré náà, ṣùgbọ́n oríkì ènìyàn nìkan ní í máa jẹ yọ nínú àwọn ìsàré náà, pàápàá oríkì bọ̀rọ̀kìnní. Bákan náà ni a sì fi hàn pé orin kò gbẹ́yìn nínú àgbékalẹ̀ àwọn ìṣàré náà.Àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ń jẹ ìyàwó lọ́kàn lóríṣiríṣi a máa súyọ ninú ẹkún ìyàwó.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣọ, tí ó sì hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ tí a fi ṣàlàyé, ẹ̀ka èdè Ilé-Ifẹ̀ ni wọ́n fi ń ré ọ̀sàrè. Àwọn ìṣàré ajẹmáyẹyẹ tí ó jẹ́ ti agbègbè ilẹ̀ Yorùbá kan pàtó bẹ́ẹ̀ pọ̀. Díẹ̀ lára wọn ni ègè dídá láàrín àwọn Ẹ̀gbá, olele mímú láàrin àwọn Ìjẹ̀ṣà, alámọ̀ṣísá laàrín àwọn Ìjẹ̀ṣà àti Èkìtì, àṣamọ̀ pípa

láàrin àwọn Èkìtì, àsíkò, lághálogho àti rẹ́sọ̀ láàrin àwọn Ọ̀wọ̀. Ẹ̀ka èdè Yorùbá ti àdúgbò kọ̀ọ̀kan ni wọ́n máa fi ń ṣe ìgbékalẹ̀ àwọn ìṣàré náà.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Jíròrò ní ṣokí ṣókí lórí oríṣi rárà mẹ́ta tí o mọ̀.
2. Ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn kókó ọ̀rọ̀ mẹ́rin tí ẹlẹ́kún ìyàwó máa ńmẹ́nu bà.
3. Ṣe àlàyé irúfẹ́ ewì alohùn tí ọ̀sàré jẹ́ ní ṣókí.
4. Jíròrò lórí àwọn àkóónú ọ̀sàré pẹ̀lú àpẹẹrẹ?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Àjùwọ̀n, B. 1989. *Ògbérè*, University Press Limited, Ìbàdàn.

Ládélé, T.A.A. àti Fáníyì, J.O.O. 1979. *Ẹkún Ìyàwó*. Longman Nigeria Ltd,Ìkẹjà.

Ọlábímtán, A. 1988. *Àkójọpọ̀ Ewì Àbáláyé àti Ewì Àpílẹ̀kọ,* PaperbackPublishers Limited,Ìbàdàn.

Ọlátẹ́jú, M. O. A. 1988. Yùngbà Royal Chant A Specialised Yorùbá Oral Poetic Type," *Òye: Ògùn Journal of Arts,* fol.1, o. i. 54 – 68 Ọ̀pádọ̀tun, Ọ. 2002. *Okòó Ewì Alohùn.* Ọ̀yọ́: Odumatt Press & Publishers.

Ọ̀pádọ̀tun, Ọ., Gbénró, D. Àti Ọmọ́làsóyè, A. 2005. *Ewì Alohùn Pẹ̀lú Fọ́nrán Onífídíò* (Apá Kìn-ín-ní). Odumat Press & Publishers,Ọ̀yọ́

Rájí, S.M.Rájí, (Àtàwọn yòókù) 2009. *Ọ̀kan-ò-jọ̀kan Ewi Alohùn Yorùbá,* Alafas Nigeria Company,Ìbàdàn.

Wolf, H. 1962 Rárà: "A Yorùbá Chant," *Journal of African Languages* fol. 1, no. 1, o. i. 87 – 116.

# ÌPÍN 5 ORIN

## AKÓÓNÚ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Orin Ọmọdé
4.1.1 Orin Ìrẹmọlẹ́kún
4.1.2 Orin Erémọdé
4.1.2.1 Orin Erémọdé Oníjẹ̀lẹ́ńkẹ́
4.1.2.2 Orin Erémọdé Onídààrayá
4.1.3 Orin Àlọ́ Onítàn
4.2 Orin Ọdún Ìbílẹ̀
4.3 Orin Àlùjó
4.3.1 Àwọn Ọ̀wọ́ Ohun Èlò Orin/ Ìlù Orin Àlùjó: Dùndún Àti Ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ Pẹ̀lú Orin Agbè/ Sàkàrá Bí Àpẹẹrẹ
4.3.2 Àkóónú Orin Àlùjó
5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Orin ni ẹ̀yà ewì alohùn Yorùbá tí ìwéhùn àti ìwọ̀hùn rẹ̀ ṣe wẹ́kú jùlọ. Ìdí nìyí tí a le patẹ́, sí i, tí a lè lùlù sí i,tí a sìlè jósí i. Oríṣiríṣi orin ni ó wà, àwọn orin kan jẹ mọ́ ẹ̀sìn nígbà tí àwọn kan kò jẹ mọ́ ẹ̀sìn. Lára àwọn orin tó jẹ mọ́ ẹ̀sìn ni orin ọdún ìbílẹ̀ àti orò àwọn òrìṣà bí i orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́/Ẹ̀fẹ̀, orin Òkè Ìbàdàn, orin Ọ̀ṣun, orin Agẹmọ, orin Edì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lára àwọn orin tí kò jẹ mọ́ ẹ̀sìn ni orin ọmọdé; bí orin ìrẹmọlẹ́kún, orin àlọ́ onítàn àti orin erémọdé, orin àtìgbàdégbà àti orin àlùjó. Orin Yorùbá fẹjú púpọ̀. Gbogbo ìṣàré àti àwọn ewì àrángbọ́ ni a lè kọrin sí, gbogbo ayẹyẹ àti àríyá, ìsìn òrìṣà àti orò wọn ni ó ní orin tí à ń kọ sí wọn. Bí àwọn Yorùbá bá ń ṣiṣẹ́ wọn a máa kọrin amúṣẹ́yá, bí inú wọn bá dùn, wọ́n lè kọ orin, bí inú wọn bá sì bàjẹ́, wọn a máa forin ṣàgbékalẹ̀ ẹ̀dùn ọkàn wọn. Wọn a sì tún máa ń fi orin ṣe ìpórógan. Èyí mú kí ìtúnpínsísọ̀rí orin ó nira púpọ̀, tí a ó bá lo ìwúlò wọn bí òdiwọ̀n ìtunpínsíọ̀rí. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, à ó ṣe àgbéyẹ̀wò díẹ̀díẹ̀ nínú àwọn ìsọ̀rí orin tí a ti mẹ́nu bà.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Nígbà tí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí yóò bá fi parí o óò ti lè ṣe àlàyé nípa ọ̀gangan ipò, ìṣeré àti àkóónú orin ọmọdé, orin ọdún ìbílẹ̀, orin àtìgbàdégbà àti àwọn orin àlùjó kan. Wà á ti lè jíròrò nípa àwọn aṣàmúlò, àkókò àmúlò, ètò ìgbékalẹ̀ ìṣeré, àwọn ohun èlò orin àti àkóónú àwọn orin náà.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. a) Kín ni orin ìrẹmọ?
   b) Ṣe ìdàkọ orin ìrẹmọ mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí ogbọ́ rí.
2. Dárúkọ orin ọdún ìbílẹ̀ méjì tí o mọ̀àti agbègbè tí wọ́n ti ń lò ó?
3. Dárúkọ orin àlùjó abáláyé méjì àti ti òde òní mẹ́ta tí o mọ̀.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Orin ọmodé

A le pín orin ọmọdé sí ọ̀nà mẹ́ta. Àwọn náà ni orin ìrẹmọ́, orin erémọdé àti orin àlọ́ onítàn. Orin ọmọdé ni orin tí àwọn ọmọdé máa ń kọ àti àwọn orin tí à ń kọ fún ọmọdé. Èyí fi hàn pé kìí ṣe pé àwọn ọmọdé nìkan ni ó máa ń kọ orin ọmọdé, àwọn àgbàlágbà, àwọn òbí ọmọdé náà máa ń kọ irú orin bẹ́ẹ̀ fún ọmọdé. Àpẹẹrẹ orin ọmọdé tí àwọn àgbàlagbà máa ń kọ ni orin ìrẹmọ, àti orin ìbejì. Lára àpẹẹrẹ orin ọmọdé tí àwọn àgbàlagbà le kópa nínú kíkọ rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ọmọdé ni orin àlọ́ onítàn náà wà. Àwọn àgbàlagbà máa ń lé orin àlọ́ fún àwọn ọmọdé lásìkò tí wọ́n bá ń pa àlọ́ onítàn fún wọn. Àwọn ọ̀wọ́ orin ọmọdé tó jẹ́ pé fúnra ọmọdé ni wọ́n máa ń kọ ọ́ ni orin erémọdé. Èyí le jẹ́ orin erémọdé oníjẹ̀lẹ́ńkẹ́ tàbí erémọdé onídàáràyá bí Ògúndèji (1991) ti ṣàlàyé rẹ̀. Orin ọmọdé le jẹ́ àjọkọ tàbí àdákọ. Orin àdákọ ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ orin ìrẹmọ nígbà tí orin erémọdé àti ti àlọ́ onítàn sábàá máa ń jẹ́ àjọkọ. Ti àjọkọ lè jẹ́ yálà alákọgbà tí ó ní bátànì lílé àti gbígbè tàbi àjùmọ̀kọ; tí gbogbo wọn ó jìjọ máa kọ papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà.

#### 4.1.1 Orin ìrẹmọ

Orin ìrẹmọ ni orin tí a fi ń rẹ ọmọdé lẹ́kún (ìrẹmọlẹ́kún), tí a fi ń rẹmọ sùn (ìrẹmọsùn), tí a sì fi ń bá ọmọ ṣeré tàbí gbé ọmọ jó (Ọládàpọ̀, 2008). Àwọn ọmọ ọwọ́ àti ọmọ ọmú nìkan ni orin yìí wà fún jùlọ. Lásìkò tí àwọn ọmọdé bá ń ké, ìyá rẹ̀ le má ráàyè láti fún n ní ọyàn, nígbà mìíràn ó le jẹ́ pé ohun tó ń ṣe ọmọdé kò jẹ mọ́ kí wọ́n fún un ní ọyàn, bóyá ó rẹ ọmọ náà tàbí kí ó fẹ́ sùn, kí oorún sì má tí ì kùn ún dáradára, tàbí kí ìyá rẹ̀ má wà ní tòsí. Ẹnikẹ́ni tí ó bá gbé ọmọ náà dání yóó máa kọrin fún un, yóò sì máa pasẹ̀ fún un. Bí ọmọ yìí bá tí ń gbọ́ ohùn dídùn yìí, yóó dákẹ́ láti túbọ̀ máa gbọ́ ọ, yóó sì fi bẹ́ẹ̀ dákẹ́ igbe tàbí kí ó sùn lọ fọnfọn. Kì í ṣe àwọn ìyálọ́mọ nìkan ni ó lè kọrin ìrẹmọ, àwọn ènìyàn tí wọ́n bá

bá wọn gbé ọmọ náà le kọrin ìrẹmọ fún ọmọ, ṣùgbọ́n tàwọn ìyálọ́mọ ló pọ̀ jùlọ. Àpẹẹrẹ irú àwọn tí wọn ó máa ń ran ìyálọ́mọ lọ́wọ́ láti gbé ọmọ ni àwọn ìyá àgbà, ẹ̀gbọ́n ọmọ náà tí ó ti dàgbà tó, alájọgbé, ẹbí, ọ̀rẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bàbá ọmọ náà a máa gbọ́mọ jó nígbà míràn.Orin ìrẹmọ kò ní àkókò kan gbòógì, gbogbo ìgbà tí ọmọ bá ti ń ké náà ni wọ́n máa ń kọ ọ́ fún ọmọ. Ìbáà jẹ́ ní òórọ̀ kùtùkùtù, ọ̀sán gangan, àṣálẹ́ tàbí ààjìn dùndùn. Ohun àkọ́kọ́ tí ó máa ń dùn mọ́ ọmo ọmú, ọmọ ọwọ́, tàbí ọmọ ìrákòrò tí wọ́n ń kọrin ìrẹmọ, fún tí wọ́n fi máa ń dákẹ́,tí wọn ó sì sùn ni ìwéhùn àti ìwọ́hùn dídùn tí a fi máa kọ orin náà.Ohun tí í máa á jẹ́ àkóónú orin ìrẹmọlẹ́kún ni bí ọmọ ṣe ṣe pàtàkì àti ṣiṣe àpọ́nlé ọmọ. Lótìítọ́ ni a sọ pé ọmọdé kò tí ì ní òye àtimọ̀tumọ́ ọ̀rọ̀ inú orin ìrẹmọ tí à ń kọ fún un, síbẹ̀ bí ẹni pé ọmọdé gbọ́ ohun tí à ń bá a sọ ni àwọn ìyálọ́mọ́ ṣe máa ń ṣàgbékalẹ̀ àwọn kókó ọ̀rọ̀ inú àwọn orin náà. Wọ́n ní ìgbàgbọ́ pé ẹlẹ́dàá ọmọ náà (orí inú rẹ̀) ń gbọ́. Wọn yóó máa sọ fún ọmọdé pé kí ó máṣe sunkún mọ́, wọn yóó máa sọ fún un pé tirẹ̀ ni àwọn ń ṣe àti pé àwọn kò le fi í sílẹ̀ nígbà kankan. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, wọ́n yóò máa wúrefún ọmọ náà. Nígbà míràn wọn a sì tún máa fi orin ìrẹmọ bá ọmọ wí tí wọ́n bá woye pé àṣejù rẹ̀ fẹ́ pọ̀ jù.

Nínú gbogbo àwọn orin ọmọdé, orin ìrẹmọ nìkan ni ọmọdé kì í ti í jẹ́ akópa tààrà. Ìdí ni pé ọmọ kò tí ì mọ nǹkankan ní ìgbà náà. Ó le jẹ́ pé a máa gbé e lọ́wọ́ tàbí kí á pọn ọ́n sẹ́yìn nígbà tí à ń kọrin fún un. Torí pé ọmọdé kì í jẹ́ akópa tààrà ni ó fa sábàbí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ orin ìrẹmọ fi máa ń jẹ́ àdákọ tàbí aláìlégbè. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọmọdé kì í jẹ́ akópa nínú orin ìrẹmọ yìí, òun ni àkọ́kọ́ òsùnsùn-afọ̀ orin náà. Ìyẹn ni pé orí rẹ̀ ni orin náà dá lé.Àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa ìṣiṣẹ́ èrò ọkàn tilẹ̀ fẹsẹ̀ ìrònú àwọn Yorùbá múlẹ̀ wí pé àwọn ọmọdé máa ń ní òye gbogbo orin tí wọ́n ń kọ fún wọn yìí nípasẹ̀ ìmísí àti ìmọ̀sílára. Kódà wọn jẹ́ kí ó yé wa pé láti inú oyún pàápàá ni irú ìmoye bẹ́ẹ̀ ti máa ń wà. Kì í ṣe ní ìgbà tí omọdé bá ń ké nìkan ni a máa ń kọ orin ìrẹmọ, bí a ti tọ́ka sí i ṣaájú. A máa ń kọ ọ́ bí ọmọdé kò bá ké, tí a gbé é lọ́wọ́, tí a sì ń bá a ṣeré. Àfojúsùn ọ̀kọ̀rin nírú àkókò yìí ni pé kí ọmọ náà má baà ké, kí ó wà ní ìdùnnú àti ayọ̀. Bí ọmọ kò tilẹ̀ ké, tí a fẹ́ rọ̀ ọ́ kí ó sùn, a lè kọrin ìrẹmọ fún un.

A le patẹ́ sí orin ìrẹmọ, a le lù ṣaworo sí i pẹ̀lú. A rí àwọn ìyálọ́mọ to jẹ́ pé ẹnu ni wọ́n fi máa ń lùlù bí wọ́n bá ti ń kọ orin yìí, èyí nílò kí wọ́n dánu dúró díẹ̀ bí wọ́n bá ti ń kọ orin yìí lọ. Bí wọ́n bá tí ń kọ orin ìrẹmọ ni wọ́n máa ń pasẹ̀ tàbí tí wọn yóò máa jó sí i. Àwọn àpẹẹrẹ orin ọmọdé nìyí:

1. Àdùnní o!
Kò roko.
Àdùnní o!
Kò rodò.
Bó bá jí a gbọ́bẹ̀ kaná.
A jẹ̀bà tán a ṣekùn rondo.

Ọmọ ọlọ́rọ̀ tí ń jẹyin awó.

2. Ó tó o
Kò roko
Ó tó o
Kò rodò
Bọ́mọ bá ń ké ìyá là á pè
Ará àdúgbò a wí pó tó

Nígbà tí ọmọ bá ń ké ni àwọn ìyálọ́mọ máa ń kọ irú àwọn orin yìí láti fi rẹ ọmọ lẹ́kún. Wọ́n sọ nínú orin 1 pé ọmọ náà kò roko, bẹ́ẹ̀ ni kò rodò. Wọ́n tún ní bí ọmọ yìí bá ti jí, ẹ̀bà ní máa ń jẹ. Èyí a sì máa mú ikùn rẹ̀ ṣe rondo. Wọn n bá ọmọ náà ṣẹ̀fẹ̀ ni. Bí ẹ̀dà ọ̀rọ̀ ni gbogbo ohun tí wọn sọ sínú orin náà. Wọ́n ń fi yé ọmọ náà pé àwọn ńtọ́jú rẹ̀ dé ojú àmì nítorí náà kò sí ìdí fún un láti máa sunkun.Nínú orin 2 ni wọ́n ti sọ pé kí ọmọ náà dákẹ́ torí pé ìyá rẹ̀ kò roko, kò sì rodò àti pé àwọn tí wọ́n gbà á sílẹ̀ lọ́wọ́ ìyá rẹ̀ ti pe ìyá rẹ̀ pé ó tín ké. Torí náà kí ó dákẹ́, ìyá rẹ̀ tí kò lọ jìnnà kò ní í pẹ́ láti gbé e. Bóyá ó ń dáná ounjẹ lẹ́yìnkùlé. Àpẹẹrẹ mìíràn láti fi rẹ ọmọdé lẹ́kún ni 3.

3. Ó tó

Ọmọ olójú lami gbéré
Ẹlẹ́rèkẹ́ rìnǹtìnrínńtín
Akígbemárùn
Má fẹkún ẹ já mi láyà
Ẹ̀yìn là á gbọ́mọ ọ́n pọ̀n
Ó tó

A fi èyí náà rẹ ọmọ lẹ́kún ni bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ohun tíọ̀kọrin sọ fẹ́ dà bí eébú, ṣùgbọ́n tí a bá tún wò ó dáradára, kì í ṣe èébú láti tàbùkù ọmọ. Láti mú kí ó ṣara gírí ni ó wà fún.“Ọmọ olójú lami gbéré” ń ṣàpèjúwe ẹkún tí ọmọń sun, “Ẹlẹ́rẹ̀kẹ́ rìnǹtìnrínńtín,” àti “Akígbemárùn”jẹ́ ẹ̀dà ọ̀rọ̀ tí ó fẹ́ fi mú kí ọmọ náà súnrakì, wọn jọ èébú ni wọn kì í ṣe èébu gan-an. Ẹ̀rẹ̀kẹ́ tí ó dára ni ó ń rí rìǹtìríńtín. Bí ènìyàn sì tilẹ̀ kígbe tí kò bá ti rùn kò tí ì búrú jù. Igbe ẹkún yẹn náà ni wọ́n fẹ́ kí ó dákẹ́ rẹ̀. Gbólóhùn “Má fẹ́kún ẹ já mi láyà” àti “Ẹ̀yìn là á gbọ́mọ ọ́n pọ̀n” ń tọ́ka pé òǹkọrin náà ti pọn ọmọ náà sẹ́yìn. Kò sí òbi tí ọmọ rẹ̀ yóó máa ké igbe àsunùndákẹ́ tí àyà rẹ̀ kò níí já. Èyí lò sì fa ìpèdè náà. Irú orín yìí tún jẹ́ bí ìdámọlẹ́kun tàbí ìbámọwí. Ẹkún nìkan ni irú àwọn ọmọ tí à ńkọrin ìrẹmọ fún fi ń tọka sí ìnira tí wọ́n bá ní, wọn kò kúkú lè sọ̀rọ̀.

Nígbà mìíràn àwọn ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-ín tàbí àlùfàńsà máa ń jẹyọ nínú orin ọmọdé. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ 4.

4. À ń dúpẹ̀ bọ̀ o
À ń dúpẹ́ bọ̀ ọ
Ọmọ ń rákò
Baba ń wo yàrá o
À ń dúpẹ́ bọ̀ o

Bí a bá wo àkóónú orin 4, ó ṣe é ṣe kí ó jẹ́ pé ìyálọ́mọ lo kọ orin yìí, ó kọ ọ́ nígbà tí ọmọ rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí níí gbẹ́sẹ̀ láti rìn ni. Ó fi àwàdà kún unpé bí ọmọ òun ṣe ń gbẹ́sẹ̀ yìí, baba rẹ̀ tí ó ti kọ yàrá òun sílẹ̀ fún ọjọ́ pípẹ́ nítorí pé òun ń tọ́mọ lọ́wọ́ yóò máa wo yàrá òun báyìí.
Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ àkóónú orin ìrẹmọlẹ́kún le jẹ́ àpọ́nlé ọmọ pọ́ńbélé. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ 5 àti 6 náà.

5. Panbotorìbótó,
Mo gbọ́mọ jó.
Panbotorìbótó,
Mo gbọ́mọ jó.
Ta ló lè bímọ̀ rẹ̀

Kó má gbé e jó?
Panboto-rìbótó,
Mo gbọ́mọ jó.
Èmí ò le gbégi jó,
N ò le gbẹ́ran jó,
Panboto-rìbótó,
Mo gbọ́mọ jó. (Rájí, àtàwọn yòókù, 2009: 148-149).

6. Bílẹ̀ bá ti mọ́ o
Tọmọ lemi ó ṣe
Bílẹ̀ bá ti mọ́ ò
Tọmọ lèmi ó ṣe
Ma sì wé gèlè gẹ́ńgẹ́
Ó dilé àbíyè
Bọ́kọ bá kọni
Ọmọ ò lè kọ́ni ò
Bílẹ̀ bá ti mọ́ ò
Tọmọ lèmí ó ṣe

Orin 5 fi àpọ́nlé ọmọ hàn gẹ́gẹ́ bí ohun tó yẹ ní gbígbé jó, èyí yàtọ̀ sí ẹran tàbí igi tí àwọn kan ń gbéjó. Ní àsìkò tí àwọn ìyálọ́mọ bá ń tọ́jú ọmọ wọn lọ́wọ́, yálà wọ́n ń wẹ̀ ẹ́, wọ́n ń para fún un tàbí tí wọn ń kùn ún lósùn, ṣùgbọ́n tí ọmọ náà ń ké ni wọ́n

máa ń kọ orin 6 yẹn jùlọ. Rírì ọmọ tàbí àpọ́nlé ọmọ ni àkóónú orin yìí. Àpẹẹrẹ orin ìrẹmọ kan tó gbajúgbajà káàkiri ilẹ̀ Yorùbá, tí ó fi àpọ́nlé ọmọ hàn ni 7.

7. Ọmọ mi ò, akúrúbete-kúbete
Ọmọ mi ò, kùrùbete-kùbete
Bí ò kú o, màá raṣọ fún un
Bí ò rùn o,màá rẹ̀gbà ọrùn
Ẹ̀gbà ọrùn tó ń ṣomọ lóge
Ẹrú mo rà lá pọ̀n ọ́ ká o
Ọmọ mi ò, akúrúbete-kúbete

Ọ̀kọrin fi àbùdá ọmọ rẹ̀ (kíkúrú tí ó kúrú) kìí nínú orin yìí. Ó jẹ́ kí ó mọ̀ pébí kò bá kú, tí kò sì ṣe àìsàn, tó bá dàgbà, òun ó ra àwọn ohun ọ̀ṣọ́ ara fún un. Ẹni tí ó yẹ láti pọ́n lé ni Yorùbá ka ọmọdé sí nítorí àwọn ni ẹ̀yìn ọ̀la àwọn òbí; àwọn ni ààrọ̀ tí àwọn òbí ó fi sílẹ̀ sáyé, àwọn ni òdòdó ẹ̀yẹ wọn. Wọ́n ní bí aládìí kò bá sí mọ́, ọmọ ní í jogún ẹbu. Ìdí nìyí tí àpọ́nlé ọmọ fi jẹ́ kókó kan pàtàkí nínú orin ìrẹmọlẹ̀kún. [wá ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ sí i láti inú Ọládàpọ̀,2008 tàbí ìbòmíràn]

## 4.1.2 Orin Erémọdé

Orin erémọdé ni àwọn orin tí àwọn ọmọdé máa ń kọ nígbà tí wọ́n bá ń ṣe erémọdé. Méjì ni erémọdé pìn sí gẹ́gẹ́ bí àlàyé Ògúndèjì (1991). Àwọn erémọdé kan wà tí kò gba kí àwọn ọmọdé sá eré sí ọ̀tún tàbí òsì kí wọ́n tó ṣe eré. Torí pé irúfẹ́ ìdárayá yìí kò gba agbára, jẹ́lẹ́ńkẹ́ ni. Èkejì ni erémọdé onídààraáya. Orin tí àwọn ọmọdé máa ń kọ sírú eré yìí gba kí wọ́n sáré kiri bí wọ́n bá ń kọ ọ́.

### 4.1.2.1 Orin Erémọdé Oníjẹ̀lẹ́ńkẹ́

Orin erémodé oníjẹ̀lẹ́ńkẹ́ ni orin tí àwọn ọmọdéń kọ nígbà tí wọ́n bá ń ṣerémọdé tí kò nílò sísáré lọ sòkè-sódò. Ojú kan náà ni wọ́n máa ń sábà wà. Tí ìjupájusẹ̀ bá máa bá irú erémọdé bẹ́ẹ̀ rìn níwọ̀nba náà ni. Àpẹẹrẹ àwọn erémọdé tí a máa ń kọrin oníjẹ́lẹ́ńkẹ́ sí ni 'Lékèélékèé bùn mí lóókan,' 'Mínímínípokán,' 'Kíni ń lẹ́jẹ̀?,' 'Pẹpẹyẹ òwúbàǹtutu,' Labalábá korò, màlúù korò,' Ìyàwó ń lọta, ìlẹ̀kẹ̀ ń ṣasọ̀' àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àwọn ọmọdé bá fẹ́ ṣe eré 'Lékèélékèé bùn mí lóókan', kò nílò kí àwọn ọmọ yìí máa sáré kiri rárá. Nígbà tí àwọn ẹyẹ lékèélékèé bá ń fò kọjá lọ ni àwọn ọmọdé yóò jáde sí ojúde, wọn yóò máa juwọ́ wọn láti ṣe bí ẹni tó fò bí ẹyẹ lékèélékèé. Wọn yóò sì máa kọrin

pé:

Lílé: Lékèélékèé bùnmí lóókan
Ègbè: Ẹyẹ àdàbà bùnmí lóókan
Lílé: Lékèélékèé bùnmí lóókan

Ègbè: Ẹyẹ àdàbà bùnmí lóókan
Àjùmọ̀kọ: Lékèélékèé bọ̀lọ̀jọ̀
Mú dúdú lọ
Mú fúnfun bọ̀ wálé
Lékèélékèé bọ̀lọ̀jọ̀
Mú dúdú lọ
Mú fúnfun bọ̀ wálé

Àwọn ọmọdé yóó máa kọ orin yìí títí tí àwọn ẹyẹ náà yóó fi lọ pátápátá tí àwọn ọmọ náà kò sì níí rí wọn mọ́. Bí àwọn ọmọ yìí kò bá ti rí àwọn ẹyẹ náà mọ́, kálukú yóò wo èékánná rẹ̀ ní ìrètí pé àwọn yóó ti ní àmì funfun funfun ní orí èékánná wọn. Àmì funfun tí wọ́n máa ní ní orí èékanná wọn yìí ló dúró fún oókan tí wọ́n ní kí lékèélékèé ó bun àwọn. Àwọ̀ funfun ni lékèélékèé máa ń ní, àwọ̀ funfun yìí ni ó jọ àwọn ọmọdé lójú lára ẹyẹ yìí tí wọ́n fi lérò pé àwọn le rí gbà nínú àbùdá náà.

Àpẹẹrẹ orin erémọdé oníjẹ̀lẹ́ńkẹ́ mìíràn ni ‘Kín ní ń lẹ́jẹ̀?’ Nígbà tí àwọn ọmọdé bá fẹ́ ṣeré yìí, wọ́n nílò láti pagbo ènìyàn bíi mẹ́fà tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ọmọ wọ̀nyí yóò dúró ti ara wọn, ọ̀kan tó jẹ́ adarí eré yóò máa béèrè nípa àwọn ẹranko, ẹyẹ, kòkòrò àti ohun ẹlẹ́mìí àyíká wọn bóyá wọ́n lẹ́jẹ̀ tàbí wọn kò lẹ́jẹ̀. Èyí tí ó ń béèrè yóó ṣàdédé fi orúkọ ohun tí kò lẹ́jẹ̀ sínú rẹ̀. Bí olùdáhùn kan bá fi le sọ pé lótìítọ́ ni ohun náà lẹ́jẹ̀, ó ti ṣì í nìyí. Ìdájọ́ tí wọ́n bá jọ fẹnu kò sí ni wọn yóò dá fún ẹni tó ṣi ìdáhùn náà. Wọ́n le sọ pé igo ni àwọn máa ṣá fún olúwa rẹ̀. Igo ni kíkan ẹ̀yìn ọwọ́ ẹni ní ìkó, èyí a sì máa dunni púpọ̀. Àpẹẹrẹ orin tí wọ́n máa ń kọ náà nìyí:

Lílé: Kí ní ń lẹ́jẹ̀?
Ègbè: Lẹjẹ-n-lẹ́jẹ̀
Lílé: Ewúrẹ̀ ń lẹ́jẹ̀?
Ègbè: Lẹjẹ-n-lẹ́jẹ̀
Lílé: Àgùtàn ń lẹ́jẹ̀?
Ègbè: Lẹjẹ lẹ́ǹjẹ̀
Lílé: Òbúkọ ń lẹ́jẹ̀?
Ègbè: Lẹjẹ-n-lẹ́jẹ̀
Lílé: Ìgbín ń lẹ́jẹ̀?
Ègbè: Irọ́ ńlá. (Ògúndíjọ, 2005: 61)

Eré ọpọlọ ni eré yìí. Elégbè kò gbọdọ̀ sọ pé “Lẹjẹ nlẹ́jẹ̀”, tí ó túmọ̀ sí “A máa lẹ́jẹ̀ dáadáa” nígbà tí òǹlérin bá dárúkọ nǹkan tí kò lẹ́jẹ̀ lára bíi igi tí ó dárúkọ gbẹ̀yìn nínú ayọlò òkè yìi. Bí ó bá lọ sọ bẹ́ẹ̀, ó ti ṣì í, torí pé igi kì í lẹ́jẹ̀, oje ni igi máa ń sun. Bí ènìyàn bá ti ṣì ìdáhùn, olùwarẹ̀ ti kùnà nìyẹn. Àkíyèsí àwọn ohun àwùjọ tí ó lẹ́jẹ̀ lára àti èyí tí kò ní ni orin yìí ń pe àwọn ọmọdé sí.

### 4.1.2.2 Orin Erémọdé Onídàárayá

Orin erémọdé onídàárayá ni orin tí àwọn ọmọdé máa ń kọ sí eré ìdárayá. Ìdárayá yìí nílò kí wọ́n sáré, kí wọ́n fò tàbí kí wọ́n máa léra wọn kiri. Wọn yóó sì máa kọ orin tó jẹ́ mọ́ eré tí wọn ń ṣe náà. Àpẹẹrẹ irú eré ìdárayá tí a máa ń kọ irú orin yìí sí ni ‘Ẹkùn mẹ́ẹ́ran,’‘Ọmọdé yìí kanmí lóówo,’ ‘Ìfò fífò,’‘Ẹ bámi gbọ́ndò yìí gbẹ,’‘Bojúbojú o,’‘Ẹ̀yin ọmọ mi dà,’‘Ẹ má wẹ̀yìn o,’ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.Bí àwọn ọmọdé bá fẹ́ ṣeré bojúbojú, bí àpẹẹrẹ, àwọn ọmọ yóó yan ènìyàn kan, òun ni wọ́n máa kọ́kọ́ bò lójú. Ẹnìkan yóó fọwọ́ bo olúwarẹ̀ lójú láti ẹ̀yìn, àwọn ọmọdé yòókù yóó lọ wá ibi kọ́lọ́fín tí wọ́n rò pé ẹni tí a bò lójú náà kò ti le rí àwọn bí ó bá lajú tán sá sí. Ẹni tí ó boni lójú yóó máa kọrin, àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ yóó sì máa gbè é níbi tí wọ́n sá pamọ́ sí.

Lílé: Bojúbojú o
Ègbè: Eeee
Lílé: Olórò ń bọ̀ o
Ègbè: Eeee
Lílé: Ṣé kí n ṣí i
Ègbè: Ṣí i
Lílé: Ẹni olórò bá mú
Ègbè: Yóó pa á jẹ

Bí ó bá ti kọrin yìí dé ibí yìí, ó máa ṣí ojú tó bò náà, òun náà yóó sì tètè fara pamọ́. Ẹni tí a bò lójú yóó máa ṣe bí ẹni tí ojú ń dùn, tí kò lajú rẹ̀ dáradára, yóò sì máa fọgbọ́n wá àwọn tí ó sá pamọ́ náà gẹ́gẹ́ bí olórò tí wọ́n tọ́ka sí nínú orin eré yìí. Òun náà yóó máa kọrin kí ó le gbọ́ ohùn àwọn ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀ níbi tí wọ́n sápamọ́ sí, kí ó sì rí wọn mú.

Lílé: Ojú ń ta ń míì
Ègbè: Yóó ta ẹ́ pa

Bí ẹni tí a bò lójú yìí bá fi rí ẹnìkan mú, ẹni tí ó mú náà ni yóó gba ipò rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹni tí a ó tún bò lójú. Ẹ̀kọ́ pàtàkì tí orin eré yìí ń kọ́ ọmọdé ni láti mọ bí a ṣe le fara pamọ́ fún ewu.
Eré mìíràn ni “ẹ má wẹ̀yìn o.” Bí àwọn ọmọdé bá fẹ́ kọrin eré yìí, àwọn ọmọ náà yóó jókòó yípo. Wọn yóò fa ara wọn lọ́wọ́ lórí ìjókòó yìí. Ẹnìkan nínú wọn yóò dìde, yóò sì mú ohun kan yálà òkútà, èso àgbáàrín tàbí kóró iṣin lọ́wọ́. Yóò sì máa saré yípo àwọn tó jókòó yìí pẹ̀lú orin tí ó ń lé, tí àwọn yòókù sì ń báa gbè é.

Lílé: Ẹ má wẹ̀yìn o
Ègbè: Wẹ̀yìnwẹ̀yìn
Lílé: Ẹ má ṣòfófó
Ègbè: Wẹ̀yìnwẹ̀yìn
Lílé: Nítorí ikú

Ègbè: Wẹ̀yìnwẹ̀yìn
Lílé: Ẹ má dalẹ̀ o
Ègbè: Wẹ̀yìnwẹ̀yìn
Lílé: Nítorí àrùn
Ègbè: Wẹ̀yìnwẹ̀yìn
Lílé: Ẹni bá wẹ̀yìn
Ègbè: Wẹ̀yìnwẹ̀yìn
Lílé: Ìkó méjè
Ègbè: Wẹ̀yìnwẹ̀yìn
Lílé: Àbàrá mẹ́jọ
Ègbè: Wẹ̀yìnwẹ̀yìn
Lílé: Ìdí ọ̀rẹ́ mi lèmi ó fi sí
Ègbè: Ìdí ọ̀rẹ́ mi jàláńkòtó
Lílé: Ìdí ọ̀rẹ́ mi lèmi ó fi sí
Ègbè: Ìdí ọ̀rẹ́ mi jàláńkòtó o

Bí ẹni tí ó lérin bá ti bá a dé ibìkan tó lápẹẹrẹ, tí ó sì ti dé ọ̀dọ̀ ọ̀rẹ́ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti sọ, yóó fi ohun tí ó mú lọ́wọ́ sí ìdí ẹni náà. Bí ẹni tí a fi nǹkan sí nídìí bá ti kẹ́fin èyí ni òun náà  yóó dìde tí yóò gba ipò éni tí ó kọ́kọ́ lé orin. Ṣùgbọ́n tí kò bá fura tí ẹni tí ó ń lewájú orin tun fi yi agbo padà dé ọ̀dọ̀ rẹ̀, yóò gba a nídìí pé kí ó dìde láti gba ipò líléwájú orin àti eré. Òun ni yóó tún ṣe bí ẹni ìṣáájú títí tí gbogbo àwọn ọmọ náà yóó fi fẹ́rẹ̀ ṣe bẹ́ẹ̀ tán. A ó rí i pé nínú àkóónú orin yìí, àwọn ọmọdé gba ara wọn ní ìyànjú láti máṣe ṣòfófò àti láti máṣe dalẹ̀. Nítorí bí àwọn ọmọ náà ṣe jókòó yípo ọ̀pọ̀ nínú wọn ni yóò rí ẹni tí aléwájú orin fi nǹkan tí ó mú lọ́wọ́ sí nídìí, wọn kò sì gbọdọ̀ tú àṣirí náà. Ẹ̀kọ́ láti máa pa àṣírí mọ́ súyọ ni ibí yìí,lára ìwà ọmọlúwàbí Yorùbá náà ni.Yàtọ̀ sí èyí àwọn ọmọ náà tún ń kọ́ láti máa fura, kí wọ́n sì yéé fi gbogbo ara jókòó.

### 4.1.3 Orin Àlọ́ Onítàn

Ní àsìkò tí àwọn ọmọdé bá ń pàlọ́ ni orin àlọ́ onítàn máa ń wáyé. Kì í ṣe gbogbo àlọ́ onítàn ni ó máa ń lórin ṣùgbọ́n àwọn àlọ́ onítàn tí ó lórin wọ́ pọ̀. Bí a bá pàlọ́ débi orin, apàlọ́ yóó lé orin, àwọn agbálọ̀ọ́ yóó sì bá a gbè é. Orin yìí máa ń mú kí àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ ó rọrùn nínú àlọ́ onítàn. Àkọtúnkọ-túnkọ ni orin àlọ́ máa ń jẹ́ nínú àlọ́ onítàn pípa. Ìdí nìyí tí àwọn ọmọdé fi máa ń nífẹ̀ẹ́ sí àlọ́ onítàn olórin ju èyíalàìlórin lọ (Ògúndèjì, 1991). O ṣe é ṣe kí àwọn ọmọdé kọ orin tí wọn ti gbọ́ ní àkókò àlọ́ pípa nígbà kan rí nígbà tí wọn kò pa àlọ́láti dára wọn lára yá.Ẹ jẹ́ kí á wo àwọn àpẹẹrẹ orin àlọ́ onítàn ìsàlẹ̀méjì yìí:

1. Lílé: Ọba Àláràn-án bẹ̀wẹ̀
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Ó bẹ kéré ẹyẹ
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Ó bẹ kèrè ẹyẹ́

Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Ó démi kìn-ìn-kin sí
Lílé: Koríko dìde
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Mèrùwà dìde
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Ká relé ọba
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Ká lọ jó bátá
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Bí bàtá ò dún
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Ká lọ jó dùndún
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Bí dùndún ò dún
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Ká lọ jó kósó
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Pigídípigìdìpi
Ègbè: Kìn-ìn-kin
Lílé: Pigídípigìdìpi
Ègbè: Kìn-ìn-kin

2. Líle: Ta ló ń pe Yèdè níbẹ̀ yẹn?
Ègbè: Yèdè
Lílé: Ìgbà tẹ́ ǹ ṣọdún nílé
Ègbè: Yèdè
Lílé: Táwa náà ń ṣorò lókò
Ègbè: Yèdè
Lílé: Yèdè ta mí ló yípo
Ègbè: Yèdè
Lílé: Emì náà ta Yèdè lọ́fà
Ègbè: Yèdè
Lílé: Ó yí gbiiri ó dodò
Ègbè: Yèdè
Lílé: Bó kú o èmi ò mọ̀ o
Ègbè: Yèdè
Lílé: Bí ò kú o èmí ò mọ̀ ò
Ègbè: Yèdè
Lílé: Òkúmàjàǹpo
Ègbè: Kánikò ò

Àwọn àgbàlagbà tí ó jẹ́ apàlọ́ ni ó máa ń lérin àlọ́ fún àwọn ọmọdé ní àkókò àlọ́ pípa, tí àwọn nááó sì máa gbe é. Ṣùgbọ́n àwọn ọmọ náà lè dá orin àlọ tí wọn ti gbọ́rí kọ fún ara wọn, tí ìkan nínú wọn yóò sì máa lérin àlọ́ náà. Èyí fi hàn pé tàgbàtọmọdé, lọ́kùnrin, lóbìnrinlólùkọrin àlọ́;

ṣùgbọ́n kò sí àní àní wí pé ọmọdé ni orin náà wúlò fún jùlọ. Àwọn ni àgbàlagbà fi ń kọ́ ní ẹ̀kọ́. [Fún ìtẹ̀síwájú àti ìgbaradì iṣẹ́ ọjọ́ iwájú, ka Babalọlá (1982) àti Ọ̀pádọ̀tun (1994) fún àpẹẹrẹ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àlọ́ àti orin wọn.]

## 4.2 Orin Ọdún Ìbílẹ̀

Oríṣiríṣi ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá. Káàkiri ilẹ̀ Yorùbá ni a sì ti lè rí wọn. Lára ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá tí ati máa ń kọrin ni Ọdún Edì àti ọdún Ọlọ́jọ́ ní Ilé Ifẹ̀, ọdún Ṣàngó ní Ọ̀yọ́, ọdún Orò ní Ìṣẹ́yìn, Igbó-Ọrà àti Ìlọràá, Ọdún Ọbàtálá ní Ẹdẹ, ọdún Ońmọ̀kàá ní Ọ̀fà, ọdún Ọ̀ṣun ní Òṣogbo, ọdún Ẹ̀yọ̀ ní Èkó, ọdún Àjàlémògún ní Ìlárámọ̀kín, ọdún Òòṣà Ògìyán ní Èjìgbò, ọdún Ògún ní Òǹdó àti ọdún Òkè Ìbàdàn, pẹ̀lú ọdún Egúngún káàkiri ilẹ̀ Yorùbá. Gbogbo ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá ni a máa ń kọrin sí. Ohun tí a bá ti pè ní ọdún, toríntìlù ni a máa ń ṣe é.

Tọkùnrin-tobìnrin ni ó lè jẹ́ ọ̀kọrin nínú ọdún ìbílẹ̀. Orin ọdún ìbílẹ̀ kọ̀ọ̀kan ni ó ní ìlù tí wọ́n máa ń lù sí i. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, àpèsì ni ìlù tí wọ́n ń lù sí orin ọdún orò, bàtá ni wọ́n ń lù nínú ọdún Ṣàngó, àràn àti agogo ni wọ́n ń lù sí orin ọdún Ifá, igbìn sì ni wọ́n ń lù níbi ayẹyẹ ọdún Ọbàtálá. Bí a ti ṣe àlàyé ṣaájú fún orin ọmọdé, ọ̀nà mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a le gbà kọ àwọn orin ọdún ìbílẹ̀ náà. Àwọn kan jẹ́ àdákọ. Àwọn orin àdákọ yìí sábà máa ń jẹ́ orin ajẹmórò. Àwọn abọrẹ̀, ẹlẹ́gùn, arùgbá òrìṣà, ìyálórìṣà àti àwọn bàbálórìṣà tó jẹ́ agbẹnusọ òrìṣà tí à ń ṣọdún rẹ̀ ni ó sábà máa ń kọ ọ́. Òmíràn ni orin àjọkọ. Ó jẹ́ àjọkọ torí pé ẹnìkan ṣoṣo kọ́ ni ó ń kọ ọ́. Oríṣi orin àjọkọ méjì ló wà. Àkọ́kọ́ ni èyí tí gbogbo àwọn tí ó ń kọrin yóò jùmọ̀ máa kọ ọ̀rọ̀ orin kan papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà. Ìkejì ni àjọkọ onílílé àti gbígbè. Tí ẹnìkan yóò máa lérin tí àwọn yòókù yóò sì máa gbè é. Nígbà míràn àwọn tí ó ń lé orin lè ju ẹyọ kan ṣoṣo lọ. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀ àwọn alerin yìí yóò máa gba orin lílé náà fún ara wọn ni. Ìyẹn ni wí pé bí ọ̀gá alérin bá ju ẹyọ kan ṣoṣo lọ, bi ọ̀kọ̀rin kan bá lérin títí, ẹlòmìíràn yóò gbà á ní ẹnu rẹ̀ tí ó bá yá.

Oríṣiríṣi kókó ọ̀rọ̀ ni ó máa ń jẹyọ nínú orin ọdún ìbílẹ̀. Èyí tí ó ṣe pàtàkì jù nínbẹ̀ ni fífi orin ṣe àpọ́nlé àti àyẹ́sí àwọn òrìṣà tí à ń ṣọdún wọn. Lára àwọn kókó tí ó tún máa ń jẹyọ nínú orin ọdún ìbílẹ̀ ni ìdúpẹ́ oore, ìwúre ọdún, ẹ̀bẹ̀, ìkìlọ̀, ìmọ̀ràn, ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ jẹ́ kí á wo àwọn àpẹẹrẹ orin ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí àti àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí ó jẹyọ nínú wọn.

Lára orin tí Ògúndèjì (1991: 112) ṣe àlàyé pé wọ́n máa ń kọnínú ọdún Ọ̀ṣun Òṣogboni:

1. Bíná fojú kodò
Yóó sinmi ariwo
Bíná fojú kodò
Yóó sinmi ariwo

Kò sórìṣà tó le bá Yèyé forí gbárí
Bíná fojú kodò
Yóó sinmi ariwo (Ọláwuni, 1979: 14 - 15)

Orin 1yìí lè jẹ́ àjùmọ̀kọ tíọ̀pọ̀ àwọn èniyàn jijọ kọ papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà. Ó jẹ́ orin tí a fi ṣàpọ́nlé agbára Yèyé Ọ̀ṣun. Òrìṣà omi ni Ọ̀ṣun, Yorùbá gbà pé omi ni ó ń pa oró iná àti pé òjò níí poró ọ̀gbẹlẹ̀. Wọ́n jẹ́ kí á mọ̀ pé alágbára ni Yèyé Ọ̀ṣun nínú orin náà nítorí pé agbára omi ni agbára rẹ̀. Ó tẹ̀ síwájú pé iná ni àwọn òrìṣà yòókù torí náà wọn kò le bá Yèyé Ọ̀ṣun forí gbárí. Ìwúre gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ máa ń jẹ́ kókó kan gbòógì nínú orin ọdún ìbílẹ̀. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ àdúrà ìsàlẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí Ògúndèjì (1991: 1) ṣe tọ́ka sí i.

2. ÒkèèBàdàn mo gbékùn dé o
Mo wá gbọmọ mi (Ọlánipẹ̀kun 1973:16)

Nínú ọdún ÒkèÌbàdàntí wọn ti máa ńkọrin yìí,orin náàlè jẹ́ orin àjùmọ́kọ. Ṣùgbọ́n ó lè jẹ́ àdákọ tí èyọ ẹnìkan bá dá a kọ. Àwọn àgàn tó ń wojú Àtàgé Ọlọ́mú orù, orìṣà Òkè Ìbàdàn ni ó máa ń kọ orin náà láti fi tọrọ ọmọ.

Nínú àwọn orin ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá kan, àwọn ọ̀rọ̀ wèréwèré tàbí fífi nǹkan ọmọkùnrin àtitọmọbìnrin ṣẹ̀fẹ̀ a máa jẹyọ. Èyí wọ́pọ̀ nínú orin Edì àti orin Òkè Ìbàdàn. Ẹ jẹ́ kí á wo àwọn orin alákọgbà 3, 4, àti 5ìsàlẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ:

3. Lílé: Mo gbọ́ kerekèú
Ègbè: Ẹran òbò lokó ń jẹ

4. Lílé: Okó ọlọ́pàá
Ègbè: Kìkì bẹ́líìtì
Líle: Okó tíṣà
Ègbè: Kìkì ṣọ́ọ̀kì

5. Líle: Jàwàjawà ẹpọ̀n
Ègbè: Máa bú mi
Lílé: Jàwàjawa ẹpọ̀n
Ègbè: Máa bú mi

Nínú orin 3 àti 4 ẹnìkan nínú àwọn òǹkọrin náà ni yóò máa lé orin tí gbogbo àwọn yòókù ó sì máa gbè é. Nínú àpẹẹrẹ 5 ẹ̀wẹ̀, ẹni tí àwọn olórin náà ń fi ṣẹ̀fẹ̀ ni ó ń gbe orin náà. Nínú ẹ̀dà orin yìí mìíràn, ó lè jẹ́ àkọgbà láàrin ọ̀wọ́ àwọn ọkùnrin àti obìnrin; tí àwọn obìnrin bá ní“Jàwàjawà ẹpọ̀n,” àwọn ọkùnrin náà a sì dá

wọn lóhùn pé, "Jàwàjawaòbò." Àwàdà àti ìdáraya ni wọ́n ń fi gbogbo rẹ̀ ṣe ní àkókò ọdún náà.

Àyè láti sọ ìsọkúsọ tí ó jẹ mọ́ ìhòòhòò èèyàn kì í fi bẹ́ẹ̀ sí ní àwùjọ Yorùbá. Bí a bá rí ọkùnrin tàbí obìnrin tí ó ń yanu sọ àwọn ìsọkúsọ bẹ́ẹ̀, aṣa àti aláìlẹ́kọ̀ọ́ ni wọn ó ka ẹni bẹ́ẹ̀ sí. Ìgbàniláàyè a máa wà ní àsìkò àwọn ọdún ìbílẹ̀ kọ̀ọ̀kan lẹ́ẹ̀kan lọ́dun láti sọ wọ́n. Àkókò yìí wà fún ìtúraka àti ìdárayá ní ìrántí akọni obìrin ìgbàanì bí i Àtàgé ọlọ́mú orù tí ó tọjú àwọn ọmọ Ìbadàn ní ìgbà ìpọ́njú wọn àti Mọrèmí ní Ilé-Ifẹ̀, tí kò ka nǹkan obìnrin rẹ̀ sí bàbàrà nígbà tí ó fẹ́ gba ìlú rẹ̀ là. Àkókò yìí nìkan ni wọ́n fi irú ààyè yí sílẹ̀ fún sísọrọ̀ wèréwèré fàlàlà. Ojú kíkorò ni wọn yóò fi wo ẹni tí ó bá tún sọ irú rẹ̀ lẹ́yìn ọdún. Wọn a tún máa lo àkókò yìí láti túṣọ lórí àṣírí ìwà ìbàjẹ́ ọlọ́jọ́ pípẹ́ tí ẹnu ẹnìkankan kò ti gbà, látẹ̀yìn wá nitorí náà ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn orin àlùfàǹsá/ìsọkúsọ/wèréwèréló tún máa ń wáyé nínú ọdún ìbílẹ̀ ní àkókò yí, tí wọ́n sì wà fún ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀. Kí ẹni tí ó hùwà ìbájẹ́ le mọ̀ pé kò dára, kí àṣírí ìwà ìbàjẹ́le tú fún aráyé rí, kí ẹlòmíràn tí ó bá tún fẹ́ hùwà ìbàjẹ́ le mọ̀ pé má-ṣé-é ni òògùn má gbọ̀ọ́. Àpẹẹrẹ orin ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ kan ni 6 nínú ọdún Òpèlú ní Kàbà gẹ́gẹ́ bí Ògúndèjì (1991:114) ṣe fi hàn.

6. O ṣàlè àgbà
   O ṣàlè ọmọdé
   O dókódókó yarọ(Mákun 1984: 54)

Obìnrin tó jẹ́ oníṣekúṣe kan ni wọ́n fi orin yìí bá wí. Ojútì ni èyí máa ń jẹ́ fún àwọn ẹni tí ọ̀rọ̀ náà kàn torí pé gbogbo ìlú ni yóó mọ ìwà àìdára tí wọ́n hù náà. Èyí sì le fa kí wọ́n sá kúrò tì ní àwùjọ nítorí ìtìjú.
Orin ọdún ìbílẹ̀ tún le dá lórí ìṣẹ̀lẹ̀ orò ọdún tí wọ́n ń ṣe lọ́wọ́ bí ati sọ tẹ́lẹ̀. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ 7 gẹ́gẹ́ bí Ògúndèjì (1991: 114 - 115) ṣe fi hàn.

7. Lílé: Tele ń rèkọ̀gún Olóńbẹ
   Ègbè: Tele ń rèkọ̀gún o
   Lílé: Tele ń rèkọ̀gún ayé gbogbo
   Ègbè: Tele ń rèkọ̀gún o (Adétipẹ́ 1989: 42)

Àsìkò tí wọ́n bá lọ mú Tele wálé nínú ọdún Edì ní Ifẹ̀ ni wọ́n máa ń kọ orin yìí. Arubi ni Tele jẹ́ nínú ọdún Edì ní Ifẹ̀, òun ni ó máa ń ru gbógbo àìdara ìlú lọ. Nínú ọdún Orò ní ìlú Igbó-Ọrà, ní àkókò tí Ìyálóde bá ń darí bọ̀ láti ibi ijó Kúṣẹndí, àwọn ẹmẹwà Ìyálóde àti àwọn ará ilé rẹ̀ máa kọrin 8 báyìí pé,

8. Lílé: Bíyàálóde kò bá ì wọlé
Ègbè: Bí ẹ bá tó bẹ́ẹ̀
Ǹjẹ́ ẹ forò hádé
Lílé: Bíyàálóde kò bá ì wọlé
Ègbè: Bí ẹ bá láyà
Ǹjẹ́ ẹ forò hádé

Obìnrin ni ìyálóde, obìnrin ò sì gbọdọ̀ wo Orò. Torí pé olóyè pàtàkì ni Ìyálóde ní àárín ìlú, àwọn olórò gbọ́dọ̀ bọ̀wọ̀ rẹ̀ kí wọn ó tó forò sé òde. Àǹfààní yìí niàwọn ènìyàn ìyálóde yóó jẹ títí tí wọn yóò fi jó wọlé kí ó tó di pé wọ́n máa fi orò sé òde.
Àwọn kókó wọ̀nyí, àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀, ni ó máa ń jẹyọ nínú orin ọdún ìbílẹ̀. Àwọn orin ọdún ìbílẹ̀ kán wà tó jẹ́ pé láti ìgbà tí ọdún yìí ti bẹ̀rẹ̀ ni wọ́n ti ń kọ ọ́. Àwọn kan sì wà tó jẹ́ pé àfikún ni wọ́n jẹ́. Àwọn orin tí ó pilẹ̀ ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí sábàá máa ń jẹ́ orin ajẹmórò ọdún nígbà tí àwọn orin tí a fi kún orin ọdún ìbílẹ̀ máa ń wà fún orin ayẹyẹ ọdún àti ìdáwọ̀ọ́ ìdùnnú ọdún lásán.

## 4.3.0 Orin Alálùjó

Àwọn alálùjó ni àwọn ẹgbẹ́ onílù àti orin papọ̀ tí wọn sí máa ń lọ ṣeré fú àwọn tí wọ́n bá ń ṣe ayẹyẹ ìdáwọ̀ọ́ ìdùnnú kan tàbí òmíràn. Orin ayẹyẹ, tí kò jẹ mọ́ òrìṣà kankan ni orin wọn.Orin kíkọni ó lóòrìn jù nínú ìṣeré wọn. Bí ìṣàré bá tilẹ̀ máa wà nínú wọn, ìwọ̀nba ni ó máa ń jẹ́. Ìlànà orin kíkọ ni a fi gbé púpọ̀ nínú àwọn òye ọ̀rọ̀ ajẹmẃì inú wọn kalẹ̀.Bí ènìyàn bá fẹ́ kí àwọn ẹgbẹ́ olórin àlùjó kan wá ṣeré fún òun, yóó ti fi ìpè náà tó wọn létítipẹ́. Ẹni tí ó bá pè wọ́n sí òde eré yóó sọ àkókò tí òun fẹ́ kí eré bọ́ sí, àwọn náà yóó sì sọ ohun tí wọ́n fẹ́ láti gbà ní ọwọ́ rẹ̀. Yátọ̀ sí pé a pe àwọn olórin alálùjó sí ibi ayẹyẹ, a ní àwọn olórin àlùjó kan tí ó máa ń kiri ibi ayẹyẹ kiri láìjẹ́ pé wọ́n pè wọ́n sí ibi ayẹyẹ náà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ irúfẹ́ àwọn òṣèré orin àlálùjó báyìí ni ó jẹ́ péẹ́gbẹ́ wọ́n kì í fi bẹ́ẹ̀ tóbi tàbí kí wọ́n jẹ́ ìlú-mọ̀-ká. Àwọn ẹgbẹ́ alálùjó kọ̀ọ̀kan ni ó máa ń gbáradì ṣíwájú eré. Ọ̀gá olórín ni ó sábàá máa ń jẹ́ olórí ẹgbẹ́. Lọ́pọ̀ ìgbà àwọn olórin náà ni ó máa ń jẹ́ onílù nínú àwọn ẹgbẹ́ alálùjó. Àpẹẹrẹ àwọn orin ìlù àlùjó Yorùbá tí wọ́n jẹ́ ti àbáláyé ni orin dùndún àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀, orin agbè/ sàkàrá, orin ọ̀gbẹ̀lẹ̀, àdàmọ̀, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Oríṣiríṣi ni ti àwọn tòde òní, Lára wọn ni orin àpàlà, sákàrà, wákà, ṣẹnwẹlẹ, fújì, àwúrebe, highlife, jùjú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ti àbáláyé ni ó kàn wá gan-an ní ìhín. Dùndún àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú orin agbè ni a óò sì fi ṣe àpẹẹrẹ. Ẹ jẹ́ kí á bẹ̀rẹ̀ láti ibi àwọn ohun èlò orin/ ìlù tí wọ́n ń lò sí wọn ná. Kí á ti ibi pẹlẹbẹ mú ọ̀ọ̀lẹ̀ jẹ nítorí pé àwọn ohun èlò orin wọ̀nyí ni ohun ìdámọ̀ àkọ́kọ́ àwọn irúfẹ́ ẹgbẹ́ olórin bẹ́ẹ̀.

### 4.3.1 Àwọn Ọ̀wọ́ Ohun Èlò Orin/ Ìlù Orin Alálùjó: Dùndún àti Ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀

Pẹ̀lú Orin agbè/ sàkàrá bí àpẹẹrẹ:

Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn orin wọ̀nyí ni ó ní irú ọ̀wọ́ ohun èlò orin/ ìlù tí wọ́n ń lò sí wọn. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ẹ jẹ́ kí á wo àwọn ọ̀wọ́ ohun èlò orin/ ìlù tí à ń lò sí àwọn orinorin dùndún àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀, pẹ̀lú orin agbè tàbí sàkàrá. Ọ̀wọ́ ìlù àti ohun èlò orin inu dùndún àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ nìyí:

1. Ìyá ìlù dùndún
2. Kẹríkẹrì
3. Omele akọ/ omele ìṣáájú
4. Omele abo/ omele ìkẹyìn
5. Gúdúgúdú
6. Ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀

Ìlù tí a gbẹ́ igi rẹ̀ tí ó lójú méji tí ihò sì wà ní ààrí rẹ̀ ni ìlù dùndún ṣùgbọ́n ààrín rẹ̀ tínínrín ju àwọn ojú rẹ̀ méjèèjì lọ. Ojú rẹ̀ ni wọ́n máa ń fi awọ bò tí wọn óò sì fi ọsán tẹ́ẹ́rẹ́t ẹ́ẹ́rẹ́ gígùn gígùn  san àn papọ̀. Àwọn ọṣán yìí náà ni a máa fún bí a ti ń fi kọ̀ngọ́ lu ojú ìlù tí ó fi ń le sọ̀rọ̀. Awọ àti aṣọ pẹlẹbẹ gígùn díẹ̀ ni wọ́n máa ń rán papọ̀ tí wọ́n fi ń ṣe apà tí wọ́n fí máa ń gbé e ìyá ìlù dùndúnkọ́ èjìká, ṣùgbọ́n aṣọ tí a lọ́ pọ bí ọ̀já ni wọ́n fi máa ń ṣe okùn àwọn ìlù dùndùn yòókù. Igi kọdọrọ ni kọ̀ngọ́ tí wọ́n fi máa ń lù ú. Ìyá ìlù ní í má tobì jù tí í sì máa sọ̀rọ̀. Bí a ṣe tò wọ́n sókè tẹ̀léra ni títóbi wọn ṣe pọwọ́ léra. Ilù ọlọ́pọ́n ni gúdúgúdú ní tirẹ̀. Ojú ọpọ́n kékeré tíwọ́n figi gbẹ́ ni wọ́n máa n fi awọ bò láti se gúdúgúdú. Awọ pelẹbẹ tó gùn mọ níba ni wọ́n sì máa fí ń ṣán an.  Wọn a máa fi ìda sí ààrin oju awọ ilù náà kí ó má baà tètè gbó ní oju kan naá tí wọ́n ti ń fi awọ pẹlẹbe náà ṣán an. Ọrùn ni wọ́n sì máa ń gbé òun kọ́, kí wọn baà lè gbé é síwájú ayà wọn níbi tí wọn óò ti máa ṣán an; kì í ṣe èjìká.

A kì í lu ìlù aláwọ sí orin agbè. Akerèǹgbè tí a fi yáláọmọ ayò,èso ìdò tàbí èso osè sín ni a máa ń lù sí i. Mímì ni a máa ń mi òun náà bí i ti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀. Wọ́n lè fí ọwọ́ gbá ìyá agbè ṣá nígbà tí wọn bá ń ṣeré.Ní agbègbè Ìlọrin, wọ́n lè fi agogo  àti àgídìgbo kún un.Afiwéoríṣi àwọn agbè tí ó wà nínú ọ̀wọ́ ohun èlò orin agbè tàbí sàkàrá bíÒgúndèjì (1979) àti Àlàbá (1985),tí wọ́n ti ṣe iṣẹ́ lórí orin agbè ṣe gbé e kalẹ̀ nìyí:

| Ògúndèjì (1979) | | Àlàbá (1985) | |
|---|---|---|---|
| 1. | Omele: | 1. | Omele/Konko |
| | i. Konko | | |
| | ii. Kunku | | |
| | iii. Ẹ̀sọ | | |
| 2. | Ẹ̀dà | 2. | Ẹ̀dà |
| | | 3. | Adámọ̀ràn |
| 3. | Ìyá agbè | 4. | Ìyá |

Àwọn ohun èlò orin wọ̀nyí yàtọ̀ díẹ̀ síra bí àtẹ òkè yìí ṣe fi hàn. Ohun tó fà èyí ni pé àkókò àti agbègbè kan náà kọ́ ni àwọn méjèèjì ṣe ìwádìí wọn. Àṣà kò dúró sí ojú kan rigidi, a máa yí padà láti ìgbà dé ìgbà àti láti agbègbèdé agbègbe. Nínú àwọn agbè yìí náà ni a ti rí ìyá ìlù, omele àti àwọn ìlù yòókù.

### 4.3.2 Àkóónú Orin Àlùjó

Àkóónú orin àlùjó kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí àwọn àkóónú oríṣìírìṣìí orin tí a ti ń jíròrò lé lórí bọ̀ láti ìbẹ̀rẹ̀. Orin ajẹmáyẹyẹ ni àwọn orin àlùjó, wọn kì í ṣe orin ajẹmẹ́sìn. Àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí ó bá ti orin ajẹmẹ́sìn mu, tí ó sì sábàá máa ń jẹyọ nínú orin àlùjó ni ìbà àti ìwúre. Bí kókó ọ̀rọ̀ irú èyí tí ó wà nínú orin ajẹmẹ́sìn bá tilẹ̀ jẹyọ nínú orin àlùjó, wọn kò wà fún ìjọ́sìn. ọ̀kọrin kàn fẹ́ fi tẹ̀lé àṣà àwùjọ nípa ìbà jíjú àti fifi ẹ̀mí ìrẹ̀lẹ̀ hàn ni tàbí kí ó fẹ́ fi dá òǹwòran rẹ̀ láranyá ni. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìbà/ìwúre ìbẹ̀rẹ̀ nínú orin agbè ìsàlẹ̀ yìí:

1. Lílé: Ọlọ́fin gbà wá o
   Ká má forí sọlẹ̀ ò
   Ègbè: Òkè Ìlùà tiwá dọwọ́ rẹ̀ o
   Lílé: Ọ̀ṣọ́ọ̀ṣì gbà wá o
   Ká má forí sọlẹ̀ ò
   Ègbè: Òkè Ìlùà tiwá dọwọ́ rẹ̀ o

Àwọn alágbè nínú orin 1 òkè yìí wúre ìbẹ̀rẹ̀ kí ìṣeré wọn lè yọrí síbi ire. Ọlọ́fin àti Ọ̀ṣọ́ọ̀ṣì ni wọ́n wúre náà sí. Torí pé iṣẹ́ tí ìbà máa ń ṣe ni orin ìwúre ìbẹ̀rẹ̀ eré agbè yìí ṣe ni a ṣe ka orin náà sí ìbà. Àwọn olórin agbè a máa tàkìtì nínú ìṣeré wọn ìdí níyí tí wọ́n fi ń bẹ àwọn orìṣà kí wọ́n gba àwọn, kí àwọn má forí sọlẹ̀. Èyí ni wọ́n fi ń ṣe àdúrà gbogbogbòò pé kí wọ́n ṣàṣeyọrí nínú ìṣeré wọn náà. Yàtọ̀ sí ìbà tàbí ìwúre ìbẹ̀rẹ̀, oríkì tún jẹ́ kókó kan tí ó máa ń jẹyọ nínú orin àlùjó. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ 2 ìsàlẹ̀ yìí láti inú orin dùndún àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀: .

2. Ọ̀rẹ́ lọ̀rẹ́ẹ̀ mi

Ọmọ igi-jẹgẹ́dẹ́
Ọ̀rẹ́ lọ̀rẹ́ẹ̀ mi
Ọmọ Yésúfù ǹlẹ́ o
Kì í ṣàjèjì o
Ọ̀rẹ́ lọ̀rẹ́ẹ̀ mi
Ọmọ igi-jẹ́gẹ́dẹ́ (Adélẹ́kàn, 1983: 94)

Oríkì orílẹ̀ ọ̀rẹ́ rẹ̀ tí òǹkọrin ń kì ni Olúòjé. Àwọn ọmọ Olúòjé ni wọ́n máa ń kì ní "Ọmọ igi jẹ́gẹ́dẹ́ etí Yemetù, ẹ̀làokò n ò gbọdọ̀ yẹyẹ ẹ̀gà." A óò rí i pé àpọ́nlé ni olórin náà fi orin náà ṣe fún ọ̀rẹ́ rẹ̀ náà nítórí, gẹ́gẹ́ bí ó ti sọ ọ̀rẹ́ gidi ni.
Kókó inú orin àlújò mìíràn ni ọ̀rọ̀ tó ń lọ ní àwùjọ.
Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ 3, 4 àti 5 ìsàlẹ̀ wọ̀nyí:

3. Ẹ jẹ́ á ṣe pẹ̀lẹ́ o
Ẹ̀yin òṣèlú, ẹ ṣe pẹ̀lẹ́ o
Iná èsìsì kì í jóni lẹ́ẹ̀mejì
Ẹ jẹ́ á ṣe pẹ̀lẹ́ o
Ẹ̀yin òṣèlú, ẹ ṣe pẹ̀lẹ́ o
Iná èsìsì kì í jóni lẹ́ẹ̀mejì
Ẹ jẹ́ á ṣe pẹ̀lẹ́ o (Fátókun 1984: 18)

Orin nípa ìṣèlú orílẹ̀ èdè Nàíjíríà ni orin àkọ́kọ́ òkè yẹn. Orin yìí jẹ́ orin ìkìlọ̀. Olórinń ki àwọn olóṣèlú nílọ̀ pé kí wọn ó rọra ṣe.Wọn a tún máa fi orin àlùjó sọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ ayẹyẹ tí wọ́n ń ṣe lọ́wọ́ tàbí èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá kan tàbí òmìràn. Ọ̀rọ̀ nípa ìgbésí ayé lẹ́yìn ìgbéyàwó, pàtàkì ọmọ àti ikú lè jẹyọ nínú orin àlùjó níbi ìgbéyàwó, ìkómọ àti ìsìnkú àgbà.Ọ̀rọ̀ nípa ìwà ọmọlúwàbí àti ìṣẹ̀tọ́ náà kì í si í gbẹ́yìn.Àpẹẹrẹ àyọlò láti inú orin àwọn alágbè níbi ìnáwó ayẹyẹ ìgbéyàwó àti òkú àgbà láwùjọ nìyí:

4. Lílé: Ìyàwó la wáà gbé o
Ègbè: Máa ró oméle
Lílé: Ọlọ́un ọ́ gbọ́mọ fúnyàwó o
Ègbè: Kóinkó Omele

5. Lílé: ... Ọlọ́mọ ...
Jájá la ó gbe
Òkú ọlọ́mọ
Ègbè: Jààjà la ó gbé e
Òkú ọlọ́mọ ò ee (Ògúndèjì, 1979: 47, 49)
[Kí akẹ́kọ̀ọ́ wá àwọn mìíràn sí i àpẹẹrẹ fúnra rẹ̀]

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣe àlàyé ohun tí orin jẹ́. A jíròrò lórí àwọn orin Yorùbá kan bí orin ọmọdé, orin ọdún ìbílẹ̀ àti orin àlálùjó.

- A tún orin ọmọdé pín sí orin àlọ́, orin ìrẹmọ, àti orin erémọdé.
- Orin erémọdé ni a sì tún tún pín sí ti oníjẹ̀lẹ́ńkẹ́ àti onídàáraya.
- Orin agbè pẹ̀lú orin dùndún àti ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ ni a fi ṣe àpẹẹrẹ orin àlálùjó.
- A ṣàlàyé nípaàwọn aṣàmúlò, àkókò àmúlò, ìṣeré, àwọn ohun èlò orin àti àkóónú gbogbo àwọn orin náà.
- Ohun kan tí ó yẹ kí átún ranra wa letí ni àwọn ọ̀nà mẹ́ta wọ̀nyí tí a sọ pé wọn máa ń gbà ṣe ìgbékalẹ̀ àwọn orin Yorùbá náà: àdákọ, àjùmọ̀kọ papọ̀ àti àkọgbà.

Ó yẹ kí á tún mẹ́nu bà á pé ìlò àwọn orin Yorùbá ti dàgbà sókè níbàámu pẹ̀lú àṣà ìgbàlódé. Ó ti kọjá bí ó ti wà nígbà ayé àwọn baba wa tí a gbé yẹ̀wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. A ti dárúkọ àwọn orin àlùjó òde òní díẹ̀ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.O yẹ kí á pe àkíyèsí sí i pé àwọn ohun èlò orin ti òde òní tún wà lóríṣiríṣi. Àwọn bí i gìtá, dùrù *key board*, ìlù *band set* àti oríṣiríṣi fèrè bíi kàkàkí (trumppet, saxophone) pẹ̀lú àwọn ẹ̀rọ gbohùngbohùn Kì í ṣe ojú agbo eré nìkan ni a ti lè gbádùn orinàlálùjó lóde òní, a lè gbádùn wọn lorí ẹ̀rọ rédíò, tẹlifíṣàn àti Fídíò. Ní àfikún à ń lo orin ìrẹmọ ní àwọn ilé ìwòsàn níbi ètò ìpàdé àwọn aláboyún àti ìyálọ́mọ. Bákan náà ni à ń lo orin àlọ́ onítàn nínú àwọn lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ òde òní àti nínú eré oníṣe lóríﬁ́dío.À ń lo gbogbo wọn, pàápàá àwọn orin àlùjó fún ìgbékalẹ̀ ìpolongo oríṣiríṣi bíi ètò ìdìbò, ètò ìkànìyàn, ètò ìlera àti ìpolówó ọjà náà. Oríṣiríṣi ni àwọn ọ̀nà tí à ń gbà lo àwọn orin ìbílẹ̀ wa ní òde òní.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ṣe ìdàkọ orin erémọdé Yorùbá mẹ́ta tí o mọ̀, kí o sì ṣàlàyé òye ọ̀rọ̀ inú wọn.
2. Lo àpẹẹrẹ tí ó péye láti ṣe àlàyé àwọn ọ̀nà mẹ́ta tí à ń gbà ṣàgbékalẹ̀ orin Yorùbá mẹ́ta.
3. Jíròrò lórí àwọn àkóónú orin ọdún ìbílẹ̀ mẹ́ta pẹ̀lú àpẹẹrẹtí ó péye.
4. Ṣe àlàyé kíkún lórí ìyàtọ̀ àárín àwọn ohun èlò orin agbè tàbí sàkàrá bí Ògúndèjì (1979) àti Àlàbá (1985) ṣe gbé wọn kalẹ̀.
5. Dárúkọ ọ̀nà ìgbàlódé mẹ́ta tí à ń gbà ṣàmúlò àwọn orin ìbílẹ̀ Yorùbá sì ṣe àpẹẹrẹ orin bẹ́ẹ̀ kọ̀ọ̀kan fún ọ̀nà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí o dárúkọ.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Àlàbá, I. O. 1985. A Socio-Stylistic Analysis of *Orin Agbè*: A Multimodal Genre of Yorùbá Oral Poetry, Àpilẹ̀kọ fún Oyè Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Ph.D., Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ìlẹ̀ Áfíríkà àti Ésíà, Yunifásítì tÈkó, Èkó.

Adélẹ́kàn, O. R. 1983. Ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ Performance in Igbó Elérin, Àpilẹ̀kọ fún Oyè Kejì, Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá Èdè àti Èdè Ìlẹ̀ Áfíríkà, Yunifásítì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Adétipẹ́, A. O. 1989. Ọdún Edì ní Ilé Ifẹ̀, Àpilẹ̀kọ fún Oyè Àkọ́kọ́, Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá Èdè àti Èdè Ìlẹ̀ Áfíríkà, Yunifásítì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Babalọlá, A. 1982. *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá: Apá Kìíní*. University Press Ltd.,Ìbàdàn.

Fátókun, W. A. A 1984. Literary Study of Àyànyẹmí Atoko–wá–gbowó–ńlé's Dùndún and Ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ Music Àpilẹ̀kọ fún Oyè M. A., Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá Èdè àti Èdè Ìlẹ̀ Áfíríkà, Yunifásítì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Makun, S. 1984. "Ritual Drama as Satire: The Case of Opelu Song-poetry Among the Owé Kàbà," *Nigeria Magazine* No. 148, o. i. 52 – 56.

Ògúndèjì, P.A. 1979. "Sàkàrá Songs in Ìṣẹmilé", B.A. Project, Department of Linguistics and African Language, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

_____________ 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. University of Ìbàdàn Centre for External Studies, ìbàdàn.

Ògúndíjọ, B. 2005.*Erémọdé*. Penthouse Publications (Nig.), Ìbàdàn.

Oyèwùsì, L. A. 1980. *Ogójì Eréṣùpá*, Thomas Nelson (Nigeria) Ltd. Lagos.

Ọládàpọ̀ Ọ, 2008. *Orin Arẹmọtẹ́ àti Agbọ́mọjó 1*, Ọlátúbọ̀sún Records,Ogúngbọlá Ventures Ltd., Ìbàdàn.

Ólánipẹ̀kun, O. 1973. Òkèèbàdà festival Chants, Àpilẹ̀kọ fún Oyè Àkọ́kọ́, Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá Èdè àti Èdè Ìlẹ̀ Áfíríkà, Yunifásítì Ìbaàdàn, Ìbàdàn.

Ọlawuni R. A. 1979. Àpilẹ̀kọ fún Oyè Àkọ́kọ́, Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá Èdè àti Èdè Ìlẹ̀ Áfíríkà, Yunifásítì Ìbaàdàn, Ìbàdàn.

Ọ̀pádọ̀tun, Ọ. 1994. *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Y-Books,Ìbàdàn.

Rájí, (Rájí, àtàwọn yòókù 2009). 2009. *Ọ̀kan-ò-jọ̀kan Ewì Alohùn Yorùbá*. Alafas Nigeria Company, Ìbàdàn.

# MÓDÙ 3 ÀLỌ́ ONÍTÀN ÀTI ERÉ ONÍṢE


Ìpín 1 Àlọ́ Pípa àti Àtúnyẹ̀wò Ìpínsísọ̀rí Àlọ́ Onítàn
Ìpín 2 Kókó Ọ̀rọ̀, Àhunpọ̀ Ìtàn, Ibùdó àti Àkókò Ìtàn
Ìpín 3 Ẹ̀dá Ìtàn, Ìfìwàwẹ̀dá àti Ìlò Èdè
Ìpín 4 Ọdún Ìbílẹ̀
Ìpín 5 Eégún Aláré


## ÌPÍN 1 ÀLỌ́ PÍPA ÀTI ÀTÚNYẸ̀WÒ ÌPÍNSÍSỌ̀RÍ ÀLỌ́ ONÍTÀN

### ÀKÓÓNÚ


1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  4.1 PípaÀlọ́ Onítàn
  4.2 Àlọ́ OnítànOlóníjàpá
  4.3 Àlọ́ Onítàn Aláìníjàpá
    4.3.1 Àlọ́ Onítàn Aláìníjàpá Olólórogún
    4.3.2 Àlọ́ Onítàn AláìníjàpáAláìjólórogún
5.0 Àgbálọgbábọ
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ìtẹ̀síwájú ìpínsísọ̀rí àlọ́ onítàn tí a ti ṣe ṣaájú ní ìpín karùn-ún módù kìń-ín-ní ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí jẹ́. Ní ìhín a óò tẹnpẹlẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ọ̀gangan ipò àlọ́ onítàn pípa, a óò sì tún fi ẹsẹ̀ ìpínsísọ̀rí tí a ṣe ṣaájú múlẹ̀ daádáa nípasẹ̀ ṣiṣe àpẹẹrẹ wọn, èyí tí a kò rí àyè ṣe tẹ́lẹ̀. Ìjíròrò wa yóò mú kí àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí a óò ṣe lẹ́yìn eléyìí túbọ̀ yéni yékéyéké.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Ní opin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín yìí, o ó ti lè ṣe àláyé bí a ti ń pa àlọ́ onítàn, àkókò tí à ń pa á, àwọn akópa nínú àlọ́ pípa, àwọn ìgbésẹ̀ inú àlọ́ pípa àti ìpèdè ìṣíde àti ìkádìí rẹ̀.O ó sì lè ṣe àlàyé ọ̀nà méjì pàtàkì tí a pín àlọ́ onítàn sí àti àtúnpínsísọ̀rí wọn pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Kín ni ìtumọ̀ àlọ́ gẹ́gẹ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀?
2. Ní gbólóhun kan tàbí méjì sọ irú ẹ̀dá ìtàn tí Ìjàpá jẹ́ lápapọ̀ nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá.
3. Kọ ìtàn àlọ́ aláìníjàpá olólórogún kan tí o mọ̀ sílẹ̀, kí osì fa ẹ̀kọ́ tí ókọ́ni yọ.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Pípa Àlọ́ Onítàn

Ní àṣáálẹ́, pàápàá ní àkókò tí òṣùpá bá ń já tòò lójú ọ̀run ni àwọn àgbàlagbà máa ń pàlọ́ fún àwọn ọmọdé láyé àtijọjù lọ. Ó yẹ kí á ṣàkíyèsí wí pé àkókò yí jẹ àkókò tí ọwọ́ dilẹ̀, lẹ́yìn tí a ti toko dé, tí àwọn ọmọ sì ti jẹun alẹ́ tán. Yorùbá kì í fí àárọ̀ pàlọ́.Ṣùgbọ́n láyé òde òní tí ayé ti dayé ọ̀làjú tí àṣà àlọ́ pípa ní àṣálẹ́ ti ń lọ sókun ìgbàgbé, àlọ́ pípa a máa wáyé ní ojú mọmọ, yálà ní ilé ẹ̀kọ́ tàbí ní orí rédíò àti tẹlifíṣàn. Àwọn àgbàlagbà ni ó máa ń jẹ́ apàlọ́ bí a ti yán án, tí àwọn ọmọdé sì máa ń jẹ́ agbálọ̀ọ́/ olùgbọ́ àlọ́.Ìdí pàtàkì tí àwọn Yorùbá fi máa ń pàlọ́ fún àwọn ọmọdé ni láti kọ́ wọn ní ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúwàbí tí wọn nílò láti máa fi gbé ìgbésí ayé rere ní àwùjọ. Wọn gbà wí pé láti kékeré ni à á ti í peékan ìrókò, tí a bá fi sílẹ̀ kó dàgbà apá kò ní í ká a mọ́. Gbogbo ẹ̀kọ́ ìwà rere tí à á fí i gbélé ayé nírọ̀rùn ni àwọn Yorùbá máa ń fi àlọ́ onítàn kọ́ àwọn èwe lẹ́kọ̀ọ́ láti píníṣín kí ó le di bárakú fún wọn. Kò léèwọ̀ bí àwọn ọmọ náà bá kó ara wọn jọ, ní ìgbà míràn, pàápàá ní àkókò tí ọwọ́ bá dilẹ̀ fún wọn tí ọ̀kan nínú wọn sì pa àlọ́ tí ó ti gbọ́ rí lẹ́nu àgbàlagbà fún àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀.

Nígbà tí a bá fẹ́ pàlọ́, ó ní àwọn ìpèdè ìṣíde tí àpààlọ́ yóò sọ. Gẹ́gẹ́ bí i ti ìṣíde àlọ́ àpamọ̀ tí a ti sọ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́kejì, módù kejì náà ni. Ó tilẹ̀ yẹ kí á rán ara wa léti ní ìhín pé àlọ́ àpamọ̀ ni apàlọ́ kọkọ máa ń pa. Lẹ́yìn náà ni àlọ́ onítàn yóò wá bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu.Ṣókí bí ọbẹ̀ oge ni abala àlọ́ àpamọ̀ máa ń sábàá jẹ́. Ó máa ń wà fún pípèsè ọkàn àwọn ọmọdé náà sílẹ̀ fún àlọ́ àpamọ̀ tí ó ń bọ̀ lọ́nà, wọ́n sì tún máa ńfi àkókò náà dúró de àwọn ọmọdé tí kò bá tètè dé sí ojú agbo àlọ́ pípa, bóya nítorí wọn ń jẹ́ iṣẹ́ fún àwọn òbí wọn. Nígbà tí ojúbá pé tán tí ẹsẹ̀ pèlé, apalọ́, tí ó lè jẹ́ ìyá tàbí bàbá àgbà yóò kọ sí gbógbó àwọn ọmọ tó wà níkàlẹ̀, àwọn náà yóò sì máa dá a lóhùn bí ó ti tọ́ báyìí pé:

Apàlọ́: Ààlọ́ oo!
Agbálọ̀ọ́: Ààlọ̀ọ̀!
Apàlọ́: Àlọ́ mi dá fùùrù gbagbòó.
Agbálọ̀ọ́: Kó má gbágbòó ọmọ mi lọ o.
Apàlọ́: Ó lérí, kòlérí, ó lérí Ìjàpátìrókò, ọkọ Yáníbo
Ó ń lọ láàrin ẹ̀pà à rípàkọ́ ẹ̀ fírífíró

Ó lọ́pẹ́lọpẹ́ gíga tí òún ga.

Oríṣiríṣi ni ẹ̀dà ìsíde yìíbí ó bá ti wù apàlọ́ ni ó lè yà á. Àwọn ọmọ tí ó jẹ́ olùgbọ́ náà yóò sì ti mọ ìdáhùn sí ọ̀nàkọ́nà tí ó bá gbé e gba níwọ̀n ìgbà tí àwọn méjèèjì kì í ti í ṣe àjèjì ara wọn. Ọhun kan tí a kò gbọdọ̀ má pe àkíyèsí sí ni pé ìpèdè àkọ́kọ́ kọ́kọ́ yẹn pé "Ààlọ́ o" tí àwọn olùgbọ́ àlọ́ ó sì dáhùn pé "Ààlọ̀" kì í yí padà. Àwọn ìpèdè tí ó tẹ̀lé èyí ni ó máa ń yí padà. Àpẹẹrẹ ẹ̀dà ìṣíde àlọ́ mìíràn nìyí:

| | |
|---|---|
| Apàlọ́: | Ààlọ́ oo! |
| Agbálọ̀ọ́: | Ààlọ̀ọ̀! |
| Apàlọ́: | Ní ìgbà kan |
| Agbálọ̀ọ́: | Ìgbà kan ń lọ ìgbà kan ń bọ̀<br>Ọjọ́ ń gorí ọjọ́ o |
| Apàlọ́: | Bàbá kan wà. |
| Agbálọ́: | Ó wà bí ẹ̀wà. |

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé tíÒgúndèjì(1991)ṣe ìtumọ̀ àlọ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀ ni èyí tí a lọ́ wérékéké. A ti ṣàlàyé tẹ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀ pé láti inú ọ̀rọ̀ ìṣe 'lọ́' tí a so àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ 'à-' mọ́ ni a ti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ náà. Èyí túbọ̀ fẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé àròsọ ni ìtan àlọ́. Àwọn apàlọ́ Yorùbá ni ó lọ́ ọ wérékéké bẹ́ẹ̀, tàbí ká sọ pé ni wọ́n hun ún pọ̀ bẹ́ẹ̀. Ìṣẹ̀lẹ̀ inú wọn kò ṣẹlẹ̀ lójú ayé, àròbájọ àwọn apàlọ́ ni. Ìdí nìyí ti àwọn Yorùbá fi ń sọ pé "Irọ́ ní ń jẹ́ àlọ́". Yàtọ̀ sí ti wí péàwọnìpèdè àkọ́kọ́kọ́inú ìṣide àlọ́ náà ń fẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé àlọ́ pípa ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀ ní pẹ́rẹ́u, ó tún fẹsẹ̀ àjọṣepọ̀ tó gún régé múlẹ̀ láàrin àpàlọ́ àti agbálọ̀ọ́. Nípa dídáhùn "Ààlọ̀ọ̀" sí ìkésíni "Àlọ́ o" tí apàlọ́ ṣe àwọn agbálọ̀ọ́fi hàn pé àwọn ṣe tán láti fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú apàlọ́ nípa jíjó sí, pípatẹ́ àti lílùlù sí pẹ̀lú gbígbe orin tí ó bá dá àti gbígba ohunkóhun tí óba sọ gbọ́.[Wo inú ìpín àkọ́kọ́ módù kejì fún irú àlàyé kan náà yìí.]

Bí a bá wo ìyókù ìpèdè ìṣíde àlọ́ náà a óò ṣàkíyèsí pé pàtakì ohun tí apàlọ́ ń ṣe níbẹ̀ ni pé ó ṣàfihàn olú ẹ̀dá ìtàn. Nígbà míràn ó lè ju olú ẹ̀dá ìtàn nìkan lọ tí yóò fi hàn. Ó lè ṣàfihàn àwọn ẹ̀dá ìtàn pàtàkì mìíràn pẹ̀lú. Bí àpẹẹrẹ "Àlọ́ mi dá fììrìgbagbòó, ó dá lórí Ìjàpá, Olókun àti Àbọ̀n-ẹyìn." (Babalọla 1973: 29). Ohun kan pàtàkì tí àwílé àwọn agbálọ̀ọ́ sí ìpèdè àlọ́ nígbà tí ó sọ pé, "Ní ìgbà kan" nínú àpẹẹrẹ2 ń tọ́ka sí nììkọjá àkókò tàbí ìgbà, bí èyí bá sì ti wà, a jẹ́ wí pé àyè tàbí ibi ìṣẹ̀lẹ̀ náà gbọ́dọ̀ wà nìyẹn. Ìdí nìyí tí àwọn awẹ́ gbólóhùnàṣàpọ̀nlé tí ó ń tọ́ka sí àkókò àti ìgbà fi máa ń wọ́pọ̀ nínu àlọ́ onítàn. "Ní ìgbà tí ....," ni atọ́ka pàtàkì irú àwọn awẹ́ gbólóhùn bẹ́ẹ̀.

Lẹ́yìn tí apàlọ́ bá ti ṣàfihàn àwọn ẹ̀dá ìtàn pàtàkì báyìí, ohun ti ó kàn ni kí ìtàn máa tẹ̀ siwájú ní pẹrẹu. Nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àlọ́ onítàn Yorùbá orin, pàápàá orin tí ó ní bátànì lílé àti gbígbèmáa ń wà nínú àlọ́ onítàn náà. Èyí a máa fi àyè sílẹ̀ fún àwọn ọmọdé tí wọ́n jẹ́ agbálọ̀ọ́ láti kópa nínú àlọ́ pípa náà ni pẹrẹu nípa gbígbe orin, pípatẹ́, lílùlù àti jíjó ijó. Èyí wà

lára ohun tí àwọn ọmọdé fí í máa gbádùn àlọ́ ní kíkún, pàápàá tí ó bá jẹ́ àlọ́ tuntun tí wọn kòtí ì gbọ́ rí. Orin inú àlọ́ a tún máa fi òté lé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ pàtàkì pàtàkì inú àlọ́. Àkọtúnkọ túnkọ sì ni irú orin bẹ́ẹ̀ máa ń jẹ́ nítorí pé a máa wáyé níbi tí àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ máa ń wà nínú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé orin ẹyọ kan náà ni a óò máa tún kọ tún kọ nínú àlọ́ kan bí ó bá jẹ́ pé ìṣẹ̀lẹ̀ oríṣi kan náà ni ó ń wáyé léráléra bí a ti tọ́ka sí i yẹn àti bí a óò tún ṣe fi hàn nígbà tí a bá ń jíròrò lórí àhunpọ̀ ìtàn àlọ́. Àyípàdà díẹ̀díẹ̀ lè wà nínú irú ọ̀rọ̀ orin bẹ́ẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó fa sábàbí orin kọ̀ọ̀kan. Nígbàmíràn ṣa o, àlọ́ onítàn kan lè ní ju oríṣi orin kan ṣoṣo lọ. Bí ìṣẹ̀lẹ̀ ìnú ìtàn bá ṣe lọ ni wọn yóò ṣe kọ orin rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ti tọ́ka sí àwọn àlọ́ onítàn tí kò ní orin náà wà pẹ̀lú.

Bí i ti ìbẹ̀rẹ̀ àlọ́ onítàn pípa, ó ní irúfẹ́ ìpèdè ìsọ̀rọ̀ǹfèsì tàbí ọ̀rọ̀ àsọgbà láàrin apàlọ́ àti agbálọ̀ọ́ tí wọ́n máa ń sábàá fi parí àlọ́.

Apàlọ́: Ìdí àlọ́ mí rè é gbáńgbáláká
Ìdí àlọ́ mi rè é gbàǹgbàlàkà
Kó gborógbó jẹ, kó má ṣe gbobì jẹ
Nítorí orógbó ní í gbóni sáyé
Obì ní í bì wọ́n sọ́run
Bí mo bá purọ́, kí agogo ẹnu mi ó má ròó
Ṣùgbọ́n bí ń kò bá purọ́, kó ró lẹ́ẹ̀mẹta o
(*Yóò fi ika ìfábẹ̀lá sí ẹ̀rẹ̀kẹ́ rẹ̀ láti ṣe)*
Pó, pó, pó
Ó ró tàbí kò ró?
Agbálọ̀ọ́: Ó ró baba.

Ìlà mẹ́wàá gan-an ni a fi da ìtàkurọ̀sọ àárín apàlọ́ àti agbálọ̀ọ́ kọ nínú àyọkà yí. Ọ̀rọ̀ àlàyé nípa bí apalọ́ ṣe gbé ìró tí ó ṣe jáde ni a kọ ní itálíìkì sílà kẹjọ; a kò kà á mọ́ ọn nítorí kì í ṣe ara ìtàkurọ̀sọ náà.Abala méjì ni ìsọ̀rọ̀ǹfèsi náà pín sí. Àkọ́kọ́ ni abala ọ̀rọ̀ tí apàlọ́ sọ tí ó parí pẹ̀lú ìbéèrè ni ìlà kẹsàn-án. Ìkejí ni ìdáhùn agbálọ̀ọ́ ní ìlà kẹwàá. nínú ìtàkurọ̀sọ yìí sí apá méjì. Apá kìn-ín-ní rẹ̀ ni ìlà márùn-ún àkọ́kọ́.Bí a bá fi ojú òye ọ̀rọ̀ tí apàlọ́ sọ wò ó, a órí i pé ìpín méjì ni abala kìn-ín-ní yẹn pín sí. Ìlà márùn-ún àkọ́kọ́ ni apá kìn-ín-ní níbi tí apàlọ́ ti gbé àmójùsùn rẹ̀ fún pípàálọ́ kalẹ̀. Ó fi ìlà méjì àkọ́kọ́ mẹ́nu lé ọ̀rọ̀ náà. A lè ṣe ìtúpalẹ̀ ohun ti ó sọ ní ìlà méjì náà báyìí: " Lái fepo bọyọ̀ ìdí tí mó fí pa àlọ́ yìí ni ....”Ìlà mẹ́rin yòókù ni ó fi ṣe ìgbékalẹ̀ ìdí náà ní pàtó. Nípasẹ̀ ìfọ̀rọ̀parokò ni ó sì fi gbé e kalẹ̀. Ó fẹ́ kí àlọ́ rẹ̀ " .... gba orógbó jẹ, kó má ṣe gba obì jẹ ....” Ó sì sọ idí tí òun fí wúre bẹ́ẹ̀; nítórí pé gbígbó ni orógbó máa ń gbóni sáyé tí obì sì máa ń bini sọ́run ni.Ohun tí àrokò ọ̀rọ̀ yí túmọ̀ sí ni pé ó fẹ́ kí àwọn ọmodé kọ́ ẹ̀kọ́ rere tí yóò mú wọn gbé ìgbé ayé ọmọlúwàbí nígbèésí ayé wọn. Kò fẹ́ kí wọn kẹ́kọ̀ọ́ burúkú nínú àlọ́ náà kí wọ́n má baà kú ikú àitọ́jọ́. Ohun tí Ìwúre rẹ̀ yí fi ṣe pàtàkì ni pé tìbitire jìjọ máa ń rìn ni. Bí ọmọdé kò bá ní ìtọni àti ìdarí tó péye, ó ṣe é ṣe kí ó jẹ́ pé ẹ̀kọ́ búrúkú ni yóòkọ́ nínú àlọ́ náà. Ìdí nìyí tí àwọn àgbàlagbà tí ó

máa ń jẹ́ apàlọ́ fi máa ń rí i dájú pé àwọn fa ẹ̀kọ́ tí wọ́n fẹ́ kí àwọn ọmọdé kọ yọ fún wọn.Nínú apá kejì (ìlà kẹfà síkẹwàá) ni apàlọ̀ọ́ ti dá ọgbọ́n láti mú àwọn èwe tí ó pàlọ́ náà fún láti nígbàgbọ́ nínú ẹ̀kọ́ pàtàkì tí ó súyọ nínú àlọ́ tí ó pa, kí ọkàn wọn sì rọ̀ mọ́ ọn.Ó kọ́kọ́ ṣàgbékalẹ̀ ìlànà tí wọn ó fi mọ òtítọ́ nínú ìlà kẹ́fà àtìkeje; bí ago ẹnu rẹ̀ bá ró lẹ̀ẹ̀mẹta, ọ̀rọ̀ rẹ̀ jẹ́ òótọ́ bí kò bá ró lẹ̀ẹ̀mẹta, a jẹ́ pé irọ́ ni. Lẹ́yìn tí ó bá ti fi ẹnu lu ago náà lẹ̀ẹ̀mẹta tan ni yóò wá béèrè bóyá óró tàbí kò ró lọ́wọ́ àwọn ọmọ náà, tí àwọn náà ó sì fi ẹsẹ̀ dídún náà múlẹ̀. Èyí sì ni ó fi hàn pé àwọn ọmọ náà gbà gbogbo ohun tí wọ́n gbọ́ gbọ́, pàápàá ẹ̀kọ́ inú àlọ́ náà. Nípari parí ni apàlọ́ yóò wá bi àwọn ọmọ léèrè oríṣiríṣi ẹ̀kọ́ tí wọ́n ti rí kọ́ nínú àlọ́ náà tí àwọn náà óò sì máa fèsì. Òun náà yóò sì tún bá wọn fi èyí tí wọn kò nbá mẹ́nu bà kún un.

## 4.2 Àlọ́ Onítàn Olóníjàpá

A ti ṣàlàyé nínú ìpín karùn-ún módù kìn-ín-ní, pé Bámgbóṣe (1969, àtúntẹ̀, 2004 ) pín àlọ́ onítàn sí ọ̀nà wọ̀nyí: asọ̀dí-abájọ, akọnilọ́gbọ́n àti olóníjàpá. A yán an pé ọ̀rọ̀ àkóónú ni ó jẹ Bámgbóṣé lógún ninú iṣẹ́ náà gan-an kì íṣe ìpínsísọ̀rí. Kò sí ìkankan nínú àwọn ìtàn àlọ́ náà tí kì í kọ́ni lọ́gbọ́n bí àpẹẹrẹ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àlọ́ onítàn olóníjàpá náà sì ni ó lè tún la ìdí abájọ kan tàbí òmíràn yéni.Ìwọ̀núbọ̀nú tó wà nínú ìpínsísọ̀rí rẹ̀ yìí ni a kò ṣe le gbára lé e dàbí alárà. Nínú ìpín karùn-ún módù kìn-ín-ní, kan náà, a pín àlọ Yorùbá sí ọ̀nà méjì gbẹrẹgẹdẹ; àlọ́ olóníjàpá àti aláìníjàpá. A tún ṣàtúnpín àlọ́ aláìníjàpá sí ìsọ̀rí kéékèkéé méjì yìí: olólórogún àti aláìjólórógun. A yán an nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìṣaájú náà pé ọ̀nà ìpínsísọ̀rí mìíràn lè wà. Bí àpẹẹrẹ ẹlòmíràn lè pín àlọ́ sí olórin àti aláìlórin, ṣùgbọ́n èyí tí a ṣe yẹn ni a óò mú lò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ti wa. Ní èrò ti wa, ó mọ́yán lórí ju èyí tía fi orin tú pín lọ. Lára àwọn ẹ̀dá ìtàn , pàápàá Ìjàpá ni wọ́n ti fẹ́ kí àwọn ọmọ náà kọ́ ọgbọ́n. Ọ̀rọ̀ ọgbọ́n kíkọ́ yìí ni ohun pàtàkì jù lọ nínú àlọ́ pípa. Ọ̀rọ̀ orin tí oríṣi àtúnpínsísọ̀rí kejì dá lé wà láti mú ìtàn dùn ni, ara ọ̀nà ìṣàgbékalẹ̀ àlọ́ ni; kì í ṣe òun ni ó ṣe pàtàkì jù lọ. Ohun tí a óò ṣe nîisinyí ni àpẹẹrẹ àwọn ìpínsísọ̀rí wa náà láti fẹ́sẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ danindánin.

Bí a ti sọ tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ àwọn àlọ́ olóníjàpá ni àwọn àlọ́ onítàn tí Ìjàpá máa ń jẹyọ nínú rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn. Lọ́pọ̀ ìgbà sì ni ó jẹ́ pé Ìjápá ni ó máa ń jẹ́ olú ẹ̀dá ìtàn ìrú àwọn àlọ́ onítàn bẹ́ẹ̀. Ó dàbí ẹni pé àwọn àlọ́ onítàn olóníjàpá Yorùbá pọ̀ ju àwọn aláìníjàpá lọ.Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́ ni Ìjàpámáa ń jẹ́ nínú ọ́pọ́lọpọ̀ àwọn àlọ́ tí ó bá ti jẹ yọ.Ìdí nìyí tí a fi sọ pé a tún lè pe àwọn àlọ́ olóníjàpá ní ọlọ́lọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́. Kò yani lẹ́nu pé àwọn Yorùbá amáa sọ pé “Ọ̀rọ̀ gbogbo kì í sé lórí alábahun.” Ìdí ni pé Ìjàpá, tí a tún mọ̀ ní Alábahun, kò ní ìwà rere kankan lọ́wọ́ nínú púpọ̀ àwọn àlọ́ Yorùbá. Ìrẹ́nijẹ, ọ̀kánjúà,ilẹ̀ dídà, olè jíjà, òfófó ṣíṣe, ìgbéraga, ànìkànjọpọ́n, ọgbọ́n ẹ̀wẹ́, ìlara, àti àwọn ìwà àìdára mìíràn ló kún ọwọ́ Ìjàpá nínú àwọn àlọ́ náà. Bí Ìjàpá bá hu àwọn ìwà burúkú rẹ̀ yìí, a máa júṣe fún un ní ìgbà àkọ́kọ́ tó hu ìwà náà, ṣùgbọ́n lẹ́yìnọ̀rẹyìn, a máa

kéèsú ìwà ibi rẹ̀. Ṣe ẹni tó bá ń yọ́lẹ̀ dà ni àwọn àgbà máa ń wí, ohun gánnágánná a máa yọ wọn ṣe. Nígbà míràn pàápàá, èrè ìwà ibi rẹ̀ a máa yọrí sí ikú.Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ àlọ́ Ìjàpá ni o lè rí kà nínú ìwé Babalọlá (1973, àti 1979 àti Òjó, 1973) ni ó ti lè rí àpẹẹrẹ oríṣiríṣiàlọ́ olóníjàpá. Nínú àlọ́ 'Ìjàpá, Ìgbín àit Abuké Ọṣìn' (Babalọlá, 1973: 103 – 106), Ìjàpá kóbá ìgbín, àna rẹ̀, nítorí ìlara tí ó ní sí i. Oko Ìgbín ṣe dáradára nítórí ó múra sí iṣẹ́,ṣùgbọ́n oko Ìjàpá tó jẹ́ ọ̀lẹ kò ṣe daádáa rárárárá. Ìdí tí Ìjàpá fi ń jowú ìgbín,ẹni tó fún un lọmọ fi ṣe aya nìyẹn, tí ó sì fi ń wá ọ̀nà bí oko ìgbín yóò ṣe di tirẹ̀. Ìjápá pa Abúké Ọṣìn sí ààlà oko Ìgbín, ó sì wọ́ òkú rẹ̀ sínú oko àna rẹ̀ náà. Òun kan náà ló yọ́ lọ purọ́ mọ́ Ìgbín, olóore rẹ̀ nígbà tí Ọba ń wá Abuké rẹ̀ náà wí pé Ìgbín ni ó pa á.Ọbá dájọ́ ikú fún Ìgbín, ṣùgbọ́n tìbànújẹ́tìbànújẹ́ ni Ìgbín fi bẹỌba pé kí ó jọ̀wọ́ jẹ́ kí wọ́n dá ọgbọ́n kan, bóyá ojú aṣebí yóò hàn, nítorí òun kò mọwọ́ mẹsẹ̀ nínú ọ̀ràn náà. Ọba fara mọ́ àbá Ìgbín, wọ́n gbé e gẹṣin, wọn sì ń kọrin tẹ̀lé e lẹ́yìn pé ọba fẹ́ dá a lọ́lá nítorí pípa tí ó pa abúké òun. Èyí nÌjàpá gbọ́ tí ó sáré lọ jẹ́wọ́, tí ọwọ́ sì bà á, tí ọba fi pàṣẹ kí wọ́n tojú aṣebi náà yọdà, kí wọ́n sì ti ẹ̀yìn rẹ̀ bọ àkọ̀ padà. Ìjàpá kérè ìwà ìkà rẹ̀, Ọlọ́run sì kó ìgbín yọ.

Nínú àlọ́ onítàn 'Ìjàpá àti Ajá lọ jí iṣu wà' (Babalọlá, 1973: 39 – 44; tún wo Òjó 1973: 44 – 51 fún ẹ̀dà míràn àlọ́ náà), ìwà ọ̀kánjúà Ìjàpá ló jẹ́ kí ọwọ́ olóko bà á. Nígbà tíyàn mútíjàpá kù násánnásán torí àìróúnjẹ jẹ, ó bẹ Ajá tí ó ń rí oúnjẹ jẹ gidigidi kí ó tó fi ọ̀nà ibi tí ó ti ń tóúnjẹ han án. Ajá mú un ló sí oko tí ó ti ń wa ẹyọ iṣu kọ̀ọ̀kan lójúmọ́. Ó sì mú kí Ìjàpa ṣe ìlérí pé òun kò ní í wà ju ẹyọ kan lọ lẹ́ẹ̀kan. ṣùgbọ́n nígbà tí ó dorí ẹlẹ́ẹ̀ketà tí wọ́n jọ lọ sóko náà, iṣu mẹ́fà nÌjàpá, olójúkòkòrò wà.Ajá ti gbé ẹyọ kan ó sì yára sá lọ sílé kí Olóko tó dé.Olókódé, ọwọ́ ba Ìjàpá níbi tí ó ti ń wọ́ rìn pẹ̀lú ẹrù iṣu tó dì gàgà-gúgú. Pòròpò ló kà, tí ó sì gbìyànjú láti di gbogbo ẹbi ọ̀ràn náà ru Ajá níwájú Ọba. Nígbà tí àwọn oníṣẹ́ Ọba délé Ajá, Ajá fi ọgbọ́n gba ara rẹ̀ sílẹ̀. Ó díbọ́n bí ẹni tí ara rẹ̀ kò yá láti odindi ọ̀sẹ̀ kan sẹ́yìn tí ó sì ń bì gọ̀ọ̀rọ̀rọ̀rọ̀níṣejú àwọn onítọ̀hún. Wọ́n gbà á gbọ́, wọ́n sì lọ sọ fún Ọba pé irọ́nÌijàpá pa mọ́ ọn. Ìjápá nìkan ni ó fojú winá, ìyà ẹ̀ṣẹ̀ náà nítorí ojúkòkòrò rẹ̀. Pípa ni wọ́n pa á nítorí ẹ̀sùn olè ni wọ́n kà sí i lẹ́sẹ̀.

Bákan náà nínú àlọ́ 'Ìjàpá, Asín àti Ọ̀kẹ́rẹ́' (Babalọlá1978: 122 – 124), ojúṣàájú ni Ìjàpá ṣe nígbà tí ó ń la Asín àti Ọ̀kẹ́rẹ́ ọ̀rẹ́ rẹ̀ níjà láàrin ọjà.Kàkà kó la ìjà náà ní ọgbọọgba Asín ni ó dójú lé tí ó kó patiyẹ bò ju ọ̀rẹ́ rẹ̀, Ọ̀kẹ́rẹ́, lọ. Èyí ló mú kí Asín gé Ìjàpá nímú jẹ, tí imú rẹ̀ sì di kánńbó di òní olónìí. Gbogbo àwọn àfihàn ìwà burúkú Ìjàpá nínú àlọ́ onítàn olóníjàpá àti àwọn ẹ̀san tí ẹ̀dá ìtàn náà ń kó lórí àwọn ìwà àìdára rẹ̀ yìí wà láti kọ́ àwọn ọmọdé níwà ọmọlúàbí lọ. Kí wọ́n lè mọ̀ pé àtubọ̀tán ìwà ibi kì í dára; àbámọ̀ ní í kẹ́yìn rẹ̀.

Àwọn àlọ́ onítàn 'Ìjàpá àti Ìyá Ẹlẹ́pà', 'Ìjàpá àti Ìyá Alákàrà', 'Ìjàpá,Àgbẹ̀ àti àwọn ọmọ rẹ̀''Ìjàpá àti Bàbá Oníkàn' pẹ̀lú 'Ìjápá àti

àwọn Èrò Ọjà' jẹ́ ẹ̀dà ìtàn kan náà; díẹ̀díẹ̀ ni wọ́n fi yàtọ̀ síra wọn. Nínú àwọn ìtàn náà Ìjàpá ńlo ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ nípa dídíbọn bí i iwinlẹ̀ tí yóò sì máa kọrin aràmọ̀ǹdà láti dẹ́rù ba àwọn ẹ̀dá ìtàn yókù, tí gbogbo wọn ó sì sá lọ. Ìjápá yóò wá ráyè jí wọn ní irètàbí ọjà wọn kó. Nínú àwọn àlọ́ náà ó ṣe bẹ́ẹ̀ fún ọ̀pọ̀ ìgbà kí ọwọ́ tó ó bà á. Ṣé ọjọ́ gbogbo ni tolè ọjọ́ kan ṣoṣo ni tolóhun. Àkíyèsí tí mo fẹ́ kí a ṣe ní ibí ni pé gbogbo ìgbà tí Ìjàpá bá ń kọrin láti fi dẹ́rù ba àwọn ẹ̀dá ìtàn yókù ni àwọn ọmọdé tí ó jẹ́ olùgbọ́ ìtàn náà máa ń ni àǹfàní láti gberin tí apàlọ́ bá dá náà tí wọn ó patẹ́, tí wọn ó lùlù tí wọn ó sì jó. Ó lè tó Ẹ̀ẹ̀mẹta sí ẹ̀ẹ̀meje nígbà míràn tí wọn ó ní irú àǹfàní bẹ́ẹ̀ bí àyè bá ti wà sí àti bí apàlọ́ báṣe fà á gùn sí. [Tún wo Ọ̀jó, 1973 fún àlọ́ Ìjápá sí i]

## 4.3 Àlọ́ Onítàn Aláìníjàpá

Ohun gbòógì tí í máa pààlà sáàrín àlọ́ olóníjàpá àti aláìníjàpá ni wìwà tí Ìjàpá máa wà nínú tólóńíjàpá, tí kì í sì í sí nínú taláìníjàpá. Ọ̀nà méjì tí a pín àlọ́aláìníjàpá sí ni tolólórogún àti tàláìlórogún. Gẹ́gẹ́ bí a ti tọ́ka sí i fún ìrọ̀rùn ìkẹ́kọ̀ọ́ ni ìpínsísọ̀rí tí a ṣe yìí, àwọn mìíràn lè wà dáadáa. Ó hàn gbangba pé ìjẹyọ àwọn ẹ̀dá ìtàn pàtàkì inú àwọn àlọ́ náà ni a lò bí òdiwọ̀n ìpínsísísọ̀rí wa yìí. Láti fi ìdí àtúnpínsísọ̀rí àlọ́ onítàn aláìníjàpá múlẹ̀ danindanin, a óò tẹ síwájú láti sẹ àpẹẹrẹ díẹ̀.

### 4.3.1 Àlọ́ Onítàn Aláìníjàpá Olólórogún

Àwọn àlọ́ aláìníjàpá olólórogún(tàbí àlọ́ onítàn olólórogún ní ṣọ́kí) jẹ́ àwọn àlọ́ onítàn tí Ìjàpá kò ti jẹ yọ bí ẹ̀dá ìtàn, ṣùgbọ́ntí a ti máa ń bá ìdílé olórogún pàdé; pàápàá jùlọ Ìyàwó àti Ìyáálé. Àpẹẹrẹ ìtàn àlọ́ 'Ìgbakọ orogún mi dà?' àti ti 'Àgbìgbò bá n gbọ́mọ mi' wà láraàwọn àlọ́ olólórogún Yorùbá tí ó gbajúmọ̀ láàrin àwọn ọmọdé. Nínú àlọ́ 'Ìgbakọ orogún mi dà?' Ìyáálé rán ìyàwó ni odò láti lọ fọ àwọn ohun èlò ìdáná,ni odò bá ṣèèṣì gbé ìgbakọ Ìyáálé lọ. Ìyáálé fi dandán lé e pé kí Ìyàwó lọ wá ìgbakọ náà gan-an wá fún òun, kò gbọdọ̀ ra òmíràn. Nìyàwó bá ń fomijé tópasẹ̀ odò lọ, bí ó ti ń kọrin tàánútàánú pé "Ìgbakọ orogún mi dà? – Tere nànà ó mà ti bódò lọ o tere ...'Ó bá oríṣiríṣi ìṣoro pàdé lọ́nà; bí àpẹẹrẹ ó bá Afabẹ́rẹ́-gúnyán fabẹ́rẹ́ gúnyán, ó bá Bàbá elégbò yànmọ̀kàntàn fi ahán lá egbò rẹ̀ dán wò, kí wọ́n tó júwe ọ̀nà ilé Olúwẹri fún ún nibí tí Olúwẹrí ti ní kí ó wọnú àgbàlá òun, kí ó ká àwọn èso mẹ́ta tí ó bá pa rọ́rọ́, wọ́n kì í nílọ̀ kí ó má ṣe ká àwọn tí ó ń ṣe kámi-kàmì-kámi. Wọ́n sì dá ìgbakọ orogún ìyáálé rẹ̀ padà fún un. Wọ́n ni tí ó bá ti rìn síwájú díẹ̀ kí ó la èso àkọ́kọ́ mọ́lẹ̀, bí ó bá dédajì ọ̀nà kí ó làkejì mọlẹ̀, bí ó bá sì délé, tí ó wọnú ìyẹ̀wù rẹ̀ ni kí ó tó làkẹta mọ́lẹ̀. Nígbà tí ó la èso àkọ́kọ́ mọ́lẹ̀, àwọn ẹrú mẹ́rìndínlógún ni wọ́n yọ sí i lọ́kùnrin lóbìnrín tí wọ́n ní Olúwẹrí ní kí àwọn máa bá a lọ ilé kí àwọn lọ máa sìn ín. Nígbà tí wọ́n délàji ọ̀nà, tí ó tún làkejì mọ́lẹ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀ dúkìá, bíi wúrà, iyùn, àti aṣọ olówó iyebíye lóriṣirísi ló rí. Ní wọ́n bá dì wọ́n lóketèlóketè, wọ́n mú ọ̀nà ilé pọ̀n. Nígbà tí wọ́n délé ówọ̀yẹ̀wù lọ, bí

wọn ṣe ní kí ó ṣe, ó sì la èso kẹta mọ́lẹ̀, ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó ni ó dà sílẹ̀ gọ̀ọ̀rọ̀gọ̀. Gbogbo ohun tí ó rí pátápátá ni ó pín sí méjì ọgbọọgba tí ó sì kó ìlàjì lọ sọ́dọ̀ Ìyáálé. Ó kọ́kọ́ kí i ó sì dá ìgbakọ rẹ̀ padà. Ó kó, ó ròyìn gbogbo ohun tí ojú rẹ̀ rí, ó sì fi ìlàjì gbogbo ohun tí ó mú bọ̀ ta á lọ́rẹ. Ó ni Ìyáálé òun ni ó sún òunbá ire náà. Ìyáálé kọ gbogbo àwọn ẹ̀bùn náà nítorí ibi tí ó fojú sí, ọ̀nà kò gbabẹ̀. Ẹ̀rí ọkàn àti ìgbéraga kò jẹ́ kí ó lè gbà á. Kàkà bẹ́ẹ̀, ó pinnu láti rin ìrinàjò tirẹ̀ náà lọ sí ọ̀dọ̀ Olúwẹri, níbi tí ó lérò pé òun náà ó ti bá òde pàdé bí í ti Ìyàwó. Ó kó àwọn ohun èlò ìdáná lọ sódò lọ fọ̀ bí í ti Ìyàwó rẹ̀, ṣùgbọ́n odò kò gbé ìgbakọ lọ ni óbá mọ̀-ọ́n-mọ̀ ti ìgbakọ sí ojúṣàn omi lódò, odò sì gbé ìgbakọ lọ lẹ́yìnọ̀rẹyìn; ni ó bá bẹ̀rẹ̀ sí tọpasẹ̀ odò lọ, ó ń kọrin ó sì ń wá ìgbakọ náà tí odò fi apàpàǹdodo gbé lọ. Bí í ti Ìyàwó , ó dé ọ̀dọ̀ Afabẹ́rẹ́-gúnyan, ṣùgbọ́n kò lè ní sùúrù fí abẹ́rẹ́ bá ẹ̀nìkankan gúnyań. Gbogbo èrò rẹ̀ ni pé níjọ́wo ni irú iyán bẹ́ẹ̀ ó tó kúnná. Ó dé ọ̀dọ̀ Bàbá elégbò yàmọ̀kàntàn, ó kọ̀ jálẹ̀ láti bá a fi ahán la egbò rẹ̀. Nígbà tí ó ṣáà dé ọ̀dọ̀ Olúwẹri tí wọ́n ni kí ó lọ já èso tí ó pa rọ́rọ́ ní àgbàlá, èyí tí ó ń ṣe kámi-kàmì-kámi, tí wọ́n ní kí ó má jàá ni ó já. Ó ni nígbà tí òun kì í ṣe dìndìnrìn, òún óò ṣe rí nǹkan tí ó dára tí ó wuyì lójú, tí òún óò wá lọ fọwọ́ ara òun já èyí tí ó rí ràkọ̀ràkọ̀, tí kò fani mọra. Nígbà tí yóò kúrò níbẹ̀, bí wọ́n ṣe sọ fún Ìyàwó, tí ó wá ṣíwájú rẹ̀ náà ni wọ́n sọ fún òun náà pé kí ó ṣe àwọn èso mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí ó já náà. Nígbà tí ó la àkọ́kọ́ mọ́lẹ̀, àwọn ìgírìpákùnrin bí i mẹ́fà ni ó yọ sí i tí wọ́n kó patiyẹ bò ó tí wọ́n fẹ́rè lù ú pa;wọ́n ní alaìgbọràn ni. O bẹ̀bẹ̀ títí, kí wọ́n tó ó fi sílẹ̀,tí wọ́n ní kí ó máa sáré lọ teteete. Gbogbo èro rẹ̀ nígbà náà ni pé bóyá bí wọ́n ṣe kọ́kọ́ ṣe fún Ìyàwó náà nìyẹn, kò kàn rántí sọ ìyẹn fún òun nílé ni. Nígbà tí ó dé ìlàjì ọ̀nà, tí ó tún là ìkejì mọ́lẹ̀ àwọn agbọ́n ni wọ́n tú jáde, tí ọ̀rọ̀ di bí o ò lọ, o yà fún mí; ọpẹ́lọpẹ́ aṣọ tí ó ró tó dà borí tí wọn kò fi ta á ní àtapa , ṣùgbọ́n ó dákú dánwò. Nígbà tí atẹ́gùn fẹ́ sí i dìẹ̀ tí àwọn agbọ́n ti fò lọ ní óbá ta jí, ó dìde nílẹ̀, ó ń wọ́ lọ ilé. Kò lè ṣí aṣọ kúrò lórí kí ara ilé má baà rí gbogbo ojú àti imú rẹ̀ tí ó ti wú kúdukùdu. Nígbà tí ó sì wọ ìyẹ̀wù, tí ó la èso kẹta mọ́lẹ̀ ogunlọ́gọ̀ ejò àti àkeekè ni ó yọ sí i tí wọ́n sì ṣán an ní àṣánpa.

Bí àhunpọ̀-ìtàn àlọ́ yìí ti lọ náà ni ti àlọ́ “Àgbìgbò bá n Gbọ́mọ Mi.” Ìyàwó lọ oko lọ ṣẹ́gi tí wọn ó fi dáná, ó sì té ọmọ rẹ̀ jòjòló sí abẹ́ igi rẹ̀gẹ̀jẹ̀ kan. Nígbà tí ó ṣẹ́gi tán tí ó ní kí òún gbé ọmọ láti máa lọ ilé ni ó bá wá ọmọ tì. Ìdàámú ọkàn bá a. Nígbà tí yóò gbé ojú sókè ó rí ẹyẹ Àgbìgbò ńlá, tí ó ti gbéọmọ rẹ̀ hanu, ni ó bá bẹ̀rẹ̀ sí í kọrin, tí ó ń sunkún, tí ó sì ń fi ohùn arò bẹ̀bẹ̀ tàánútàánú pé kí Àgbìgbò gbé ọmọ oùn fún òun. “Àgbìgbò bá n gbọ́mọ mi o - Ẹyẹ Ìgbò; Aládé orí igi - Ẹyẹ Ìgbò...” Lẹ́yìn ìgbà pípẹ́ tí ó ti ń bẹ Àgbìgbò ni ẹyẹ náà sọ fún ún pé tí ó bá di ọjọ́ méje kí ó wá pàdé òun láti gba ọmọ rẹ̀ padà. Ìbànújẹ́ dorí obìnrin yìí kodò, ó wa ẹkún mu lọ sí ilé. Ìyáálé rẹ̀ kò tilẹ̀ kááánú rẹ̀ pẹ̀ẹ̀pẹ́ẹ̀, igi tí ó lọ ṣẹ́ lóko ni ó kọ́kọ́ ńbéèrè, kò béèrè ọmọ. Nígbà tí ó wa béèrè lẹ́yìnọ̀rẹyìn, ènìyàn mọ̀ pé ojú ayé ni ó ń ṣe. Ìyàwó kò lè jẹun fún odindi ọ̀sẹ̀ kan tí ó fi dúró de àdéhùn Àgbìgbò. Nígbà tí ìje pé Ìyàwó jí lọ sóko láfẹ̀mọ́jú, orí igi náà ni ó sì bá Àgbìgbò àti ọmọ rẹ̀, tí ó gbé hanu.

Ló bá tún bẹ̀rẹ̀ sí í kọ orin láti bẹ̀bẹ̀. Àfi pọ̀ọ̀ tí Àgbìgbò ju àpò owó sílẹ̀. Obìnrin náà kò tilẹ̀ wò ó lẹ́ẹ̀mejì orin ẹ̀bẹ̀ fún ọmọ rẹ̀ ni ó tún kì bọ ẹnu. Àgbìgbò tún ju ẹrù àṣọ àti ohun àlùmọ́nì oríṣiríṣi sílẹ̀, ṣùgbọ́n obìnrin náà ṣá ní, ọmọ òun ni òún ń fẹ́, òun kò fẹ́ owó, aṣọ tàbí ohun ọrọ̀ kankan.

Lẹ́yìnọ̀rẹyìn ni Àgbìgbo ju ọmọ rẹ̀ sí i, tí ó sì hán an pọ́nkán; inú rẹ̀ dùn, ó sì ń dúpẹ́ lọ́wọ́ Àgbìgbò. Agbìgbò ní gbobgo àwọn nǹkan yòókù náà ni kí ó maa kó lọ. Ó sì tún fún un ní ẹrúkùrin mẹ́fà àti ẹrúbìnrín mẹ́fà pẹ̀lú; àwọn ni wọ́n báa ru gbogbo ẹrù náà lọ sílé. Ìyàwó kó, ó rò fún ìyáálé rẹ̀, ósì kó ìlàjì ohun gbobgo tí Àgbìgbò fi ta á lọ́rẹ fún un. Ìyáálé kọ̀, òun náà sì pinnu láti gbé ọmọ rẹ̀ lọ síoko igi bí i tìyàwó rẹ̀. Óṣe bẹ́ẹ̀ fún ọjọ́ pípẹ́ kí Àgbìgbò tó ó gbé òun náà lọ́mọ. Òun náà kọrin bẹ Àgbìgbò títí tí onítọ̀hún fi ní kí ó padà wá ní ọ̣́ keje. Inú rẹ̀ dùn. Kò banújẹ́ kankan, tí ó bá tilẹ̀ ṣomi lójú rárá, ojú ayé ni ófi. Nígbà tí ijé pé, ó lọ pàdé Àgbìgbò ní fẹ̀rẹ̀mọ́jú. Ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í kọrin bẹ̀bẹ̀ fún ọmọ rẹ̀. Nígbà tí ó yá Àgbìgbò ya apá ọmọ rẹ̀ kan, ó sọ ọ́ sílẹ̀, nígbà tí ó tún ṣe sàà, ó ya apá kejì, ó sọ ọ́ sílẹ̀ fún un. Gbogbo èrò obìnrin náà ni pé bí ó ṣe ṣe fún Ìyàwó náà nìyẹn. Kì í ṣe apá nìkan ni Àgbìgbò ya mọ, ó ya ẹsẹ̀ méjèèjì pẹ̀lú. Níparíparí ni ó ju èkùtu ọmọ rẹ̀sílẹ̀ fún un tí ó sì fò lọ. Tìbànújẹ́tìbànújẹ́ ni Ìyáálé bá pàdà sílé.

Àwọn àpẹẹrẹ àlọ́ aláìníjàpá olórogún mìíràn ni ìtàn 'Orogún Méjì àti Ẹyẹ Ọṣìn', 'Lẹ́yẹníbi àti Orogún Rẹ̀', 'Orogún Méjì àti Ọkọ Wọn' àti 'Ìyálé Gbé Ọmọ Ìyàwó Rẹ̀ sínú Ọtí'(Ọ̀pádọ̀tun, 1994: 26 – 27, 30 – 31, 46 – 47, 63 – 65). Bákan náà ni ìtàn 'Fágoróyè ati Ọmọ Rẹ̀' pẹ̀lú ìtàn 'Ìbàràtielè' àti 'Igi Igbó Mẹ́ta tí Ó di Ìyàwo' (Àpáta, a kò mọ ọdún: 21 – 24) [Kí akẹ́kọ̀ọ́ ka àwọn àlọ́ wọ̀nyí tàbí kí ó wá àwọn àpẹẹrẹ miíràn sí i fúnra rẹ̀]

## 4.3.2 Àlọ́ Onítàn Aláìníjàpá Aláìjólórogún

Àwọn àlọ́ onítàn tí kò sí ìjápá nínú wọn, tí kò sì tún sí tìyáálé tìyàwó nínú wọn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn ni a pè ní aláìníjàpá àláìjólórogún. Irú àlọ́ onítàn bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ èyí ti afi sọ ìdí abájọ kan tàbí òmíràn tàbí èyí tí a fi kọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ ìwà rere kan tàbí èkejì. Gbogbo iṣẹ́ yìí náà ni a lè fi àwọn àlọ́ onítàn tí a ti sọ̀rọ̀ lé lóríjẹ́. Ohun tí ó ya ọ̀wọ́ àwọn ìtàn àlọ́ tí a fẹ́ ṣe àpẹẹrẹ wọn ní ìsinsìnyí sọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú ni pé kì í sí Ìjàpá àti àwọn Ìyáálé pẹ̀lú Ìyáálé nínú wọn.

Àpẹẹrẹ àlọ́ onítàn aláìníjàpá aláìjólórógún nigbogbo àwọn àlọ́ onítàn mẹ́fẹ̀ẹ̀fà tí ó wà nínú ìwé àkójọ àlọ́ *Àṣàyàn ìtàn ọmọ Obòkun* tí Ólurẹ̀mí Ọnàsànyà (1973) kọ. Olúrẹ̀mí Ọnàsànyà jẹ́ apààlọ́ lórí ẹ̀rọ rédìò ní àwọn ọdún 1960. Àkọlé ètò orí Rédíò Orílẹ̀èdè Nàìjíríà (Radio Nigeria) tí ó ti máa ń pààlọ́ onítàn ní aràarọ̀ ọjọ́ àbámẹ́ta ni "Ọmọ Obòkun ń Kí Yín."Méjì lára àwọn àlọ́ rẹ̀ tí a óò fi ṣe àpẹẹrẹ ní ìsinyí ni àlọ́ 'Aláṣejù, Ìyàwó ọba Èjìgbòmẹkùn' àti 'Àná, Òní, Ọ̀la àti Ẹnìyàn.'Nínú ìtàn àlọ́

'Aláṣejù, Ìyàwó ọba Èjìgbòmẹkùn,' Ẹwà ni orúkọ ọmọge awẹ́lẹ́wà kan tí ó wá sí ọjà Èjìgbòmẹkùn ni ọjọ́ kan, tí Ọba ìlú sì ní àfi dandan bí òún fi ṣe aya. Ó rán Aṣípa, ọ̀kan nínú àwọn ìjòyè rẹ̀ pàtàkì àti àwọn ìránṣẹ́ rẹ̀ láti tẹ̀lé Ẹwà láti mọ abúlé rẹ̀ ní ọ̀nà jíjìn réré. Ìgbéraga àti agídí ọmọbìnrin náà pọ̀ púpọ̀ tí kò níọ̀rẹ́ní abúlé rẹ̀, àyàfi Àìsinmi, tí ó jẹ́ ọmọ ìyá rẹ̀: àwọn nìkan ṣoṣo ni wọ́n sì jọ ń dá gbé. Àwọn ará abúlé Ẹwà ròyìn fún Aṣípa pé Ẹwà kò níwà rárá. Nígbà tí ó padà dé ọ̀dọ̀ Eléjìgbò ti ó ran an níṣẹ́ Aṣípa ròyìn fún un pé Ẹwà kàn lẹ́wà lásán ni o, kò níwà olóókan. Ọba ṣá fi dandan lé e pé òun ó fẹ́ Ẹwà.Àwọn ohun ìyàlẹ́nu tí Ẹwà pa ní dandan pé Ọba Èjìgbòmẹkùn gbọ́dọ̀ ṣe kí òún tó lè di ìyàwó rẹ̀ ní pé ó gbọ́dọ̀ fẹ́ òun pẹ̀lú Àìsinmi, ọmọ ìyá òun, ó gbọ́dọ̀ bẹ́ orí gbogbo olorì rẹ̀, tí ó fẹ́ ṣaájú rẹ̀ àtiàwọn ọmọ wọn, ó sì gbọ́dọ̀ dáná sún gbogbo dúkìá tí ó wà láàfin, kí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ ra tuntun. Gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyí  ni Kábíyèsí ṣetán láti ṣe. Ọpẹ́lọpẹ́ Aṣípa tí ó dá ọgbọ́n láti lọ kó gbogbo àwọn ènìyàn àti dúkìaá náà pámọ́ sí oko kan tí ó pa ewúrẹ́ tó sì fi ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ pa idà rẹ̀ tí ó lọ fi han ọba gẹ́gẹ́ bí ẹ̀rí pé òun ti mú àṣẹ rẹ̀ ṣẹ.

Lọ́jọ́ tí wọ́n lọ mú Ẹwà wá sílé ọkọ rẹ̀ tuntun, kò rí ẹnìkan fi àdúrà sìn ín lọ sílé ọkọ. Gbogbo ohun tí ó bá ti fẹ́ ni Ọbá pa láṣẹ pé kí wọ́n máa ṣe. Ó ni kódà bí ó bá ṣe orí òun alára ni óní òún fẹ́ kí wọ́n bẹ́ ẹ. Ẹwà bẹ̀rẹ̀ sí í pàṣe oríṣiríṣi. Ó ní kí wọ́n bẹ́ igi, kí wọ́n sì gbọ́n odò kúrò lọ́nà, kí òún lè ráyè kọjá. Gbogbo rẹ̀ ni wọ́n ṣe. Pa banbarì rẹ̀ ni pé ó ní kí wọ́n bẹ́ orí àwọn ènìyàn kí òún lè rọnà yan lọ bá ọkọòun, Eléjìgbò. Orin kíkọ ni ó fi ń pa àwọn àṣẹ wọ̀nyí. Kín ni àwọn dòǹgárì gbọ́ èyí sí ni wọ́n bá bẹ̀rẹ̀ sí í bẹ́ orí lọ. Wọ́n bẹ́ orí Àìsinmi, ọmọ ìyá rẹ̀, kódà wọn kò dá orí tirẹ̀ gan-an alára sí. Ọba Eléjìgbòmẹkùn tí ó wá pàdé wọn lọ́nà gan-an bá ẹsẹ̀ rẹ̀ sọ̀rọ̀ ni wọn kò fi rí orí rẹ̀ gé. Ọpẹ̀lọpẹ́ Ọ̀sanyìn tí ó gbà á sílẹ̀ tí ó sì dá wọn lẹ́kun. Ó wá ní kí wọ́n lọ kó gbogbo àwọn olorì, ọmọ àti dúkìá tí Aṣipá kó pamọ́ sókó wá, Ó sì bá Ọba náà wí, pé ó jẹ́ kí ẹwà  wọ òun lójú, tí kò fi bìkítà fún ìwà.

Nínú ìtàn àlọ́ 'Àná, Òní, Ọ̀la àti Ẹniìyàn,'Tẹ̀gbọ́n tàbúrò ni Àná, Òní àti Ọ̀la, ọmọ Aṣẹ̀dá. Baba wọn ló ran wọn wá sílé ayé láti wá tún ilé ayé ṣe. Nígbà tí wọ́n débẹ̀ wọ́n ń ṣe iṣẹ́ wọn bí iṣẹ́, wọn sì n bọ̀wọ̀, tí ó tọ́ fún Ọ̀la tí ó jẹ́ ẹ̀gbọ́n wọn pátápátá, ẹni tí bàbá wọn gbé àṣẹ lé lọ́wọ́. Ìyàn ló lé ẹnìkan kúrò ní ìlú tirẹ̀ tí ó fi sá  dé ọ̀dọ̀ àwọn tẹ̀gbọ́n tàbúrò náà. Wọ́n gbà á tọwọ́tẹsẹ̀, wọn bu ilẹ̀ oko ati ilẹ̀ ilé fún un, wọ́n sì ń pè é ni Ẹniìyàn tórí ìyàn ni ó lé e dé ọ̀dọ̀ wọn. Lẹ́yìn ìgbà díẹ̀, òun náà jẹ bò, ó sì tilẹ̀ là, ó lu pẹ̀lú. Nígbà tí ara tù ú tán ó gbe ẹ̀wù ìgbéraga wọ̀, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í yájú sí àwọn olóore rẹ̀, pàápàá Ọ̀la. Ó ní ẹgbẹ́ ni àwọn; òún tilẹ̀ jù wọ́n lọ, àti pé òun gbọ́dọ̀ bórí Ọ̀la, tí ó jẹ́ ẹ̀gbọ́n wọn. Nígbà tí Èṣù gbọ́, ó ní kí Ẹniìyàn rúbọ, kí ó lè borí nítòótọ́, nítorí ní ìgbèrí odò ni Ọ̀la fi àṣẹ rẹ̀ pamọ́ sí. Ṣùgbọ́n ó kọ̀ láti rúbọ nítorí pé ó ti gbọ́ ibi tí agbára Ọ̀lá wà ná. Èṣù lọ sọ fún Ọla náà kí ó rúbọ, kí apá ọ̀tá má lè ká a. Òún sì rúbọ ní tirẹ̀. Ẹniìyàn gbé ìgbésẹ̀ nítòótọ́ láti lọ jí agbára àṣẹỌ̀la ní ìgbèrí ọdò, ṣùgbọ́n olobó ti ta Ọla, ó sì ti pa ọwọ́ ibi tí ó fi agbára náà sí dà. Ẹniìyàn

mófo, Olúwẹri ni ó kò lọ́nà, ó sì fi ojú rẹ̀ han màbo. Ójẹ́ kí ó mọ̀ wí pé Ọla ni àgbà ẹnikẹ́ni.

Ohun kan tí afẹ́ pe àkíyèsí sí ni pé ènìyàn ni gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àwọn àlọ́ mẹ́fẹ̀ẹ̀fà inú àwọn ìtàn Ọmọ Obòkun tí a mẹ́nu bà gẹ́gẹ́ bí méjì tí a ṣe ìsọníṣókí wọn yìí ṣe fi hàn. Àwọn àlọ́ onítàn aláìníjàpá aláìjólórógún wà dáadáa tí àwọn ẹ̀dá ìtàn inú wọn jẹ́ ẹranko, tàbí àpapọ̀ ènìyàn pẹ̀lú àwọn abàmì ẹ̀dá ìtàn mìíràn bí, igi igbó, iwin, òkú abbl.

Nínú ogún àlọ́ àpamọ̀ tí Pọ̀jù Àmọ̀rí kó jọ sínú ìwé *ÌdíAbájọ Kìnnìún àti ÀwọnẸranko Mìíràn*, tí wọ́n jẹ́ àlọ́ onítàn tí a fi sọ ìdíabájọ ìrísí tàbí ìṣe àwọn oríṣiríṣi ẹranko àti ẹyẹ, ẹyọ kan ṣoṣo ni ó dálé oríÌjàpá. Mọ́kàndínlógún yòókù jẹ́ ti oríṣiríṣi ẹranko àti ẹyẹ. Lára wọn ni àlọ́ 'Ìdí Abájọ tí Kìnnìún fi ń Bú,' 'Ìdí Abájọ tí Ọrùn Ògòǹgò fi Gùn tó Bẹ́ẹ̀,''Ìdí Abájọ tí Adìẹ fi ń Ṣàlẹ̀ Jẹ,''Ìdí Abájọ Kíké Ọ̀pọ̀lọ́' àti 'Ìdí AbájọẸ̀rín Ìkookò.'Atún lè rí àpẹẹrẹ àlọ́ aláìníjàpá aláìjólórogún nínú àkójọpọ̀ *Àwọn ìtàn aládùn* tí Aya F. O. Àpáta ( a kò mọ ọdún) kó jọ. Lára wọn ni 'Ìtàn Ọba Aláràn-án ati Ẹyẹ Kinkin' (o. i. 3 – 5),'Ọlọ́rànmọdùn' ( o. i. 9 -11), 'Ìyàwó àti Ẹrú' (14 – 16), 'Ègùnmọ̀ àti Ọ̀pẹ' (o. i. 20 - 21), 'Ọba Olómù' ( 25 – 27), 'Arìẹgẹ' (o. i. 27 – 29) a. b. b. l.Àwọn ìwé àkójọpọ̀ àlọ́ onítàn mìíràn náà sì wà tí ó ti lè rí àwọn àpẹẹrẹ sí i.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín kìn-ín-ní módù kẹta yìí, a tẹnpẹlẹmọ́ ìgbéyẹ̀wò ọ̀rọ̀ àlọ́ pípa àti àtúnpín-sísọ̀rí àlọ́ onítàn.

- A ṣe àlàyé nípa àwọn akópa nínú àlọ́ onítàn pípa àti àsìkò tí wọ́n máa ń pa a.
- A ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìgbésẹ̀ inú àlọ́ pípa.
- A jíròrò nípa àwọn ìpèdè tí a máa ń fi ṣidé àlọ́ onítàn.
- A sọ̀rọ̀ nípa ìtumọ̀ àlọ́ gẹ́gẹ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀.
- A mẹ́nu ba ipò àti ipa orin nínú àlọ́ onítàn.
- A sì ṣe àlàyé nípa ìpèdè ìkádìí àlọ́ onítàn pípa.
- Bákan náà ni a rán wa létí pé ọ̀nà méjì gbẹrẹgẹdẹ tí a pín àlọ́ onítàn sí ni ti olóníjàpá àti aláìníjàpá, àti pé a tún ti aláìníjàpá pín sí olólórogún àti aláìjólórogún.
- A gbìyànjú pẹ̀lú láti fẹsẹ̀ ìpínsísọ̀rí àlọ́ onítàn tí a ṣe múlẹ̀ nípa ṣíṣe àpẹẹrẹ àti títọ́ka sí ibi tí akẹ́kọ̀ọ́ ti lè rí àpẹẹrẹ síwájú sí í.

Ohun kan ti ó yẹ kí o mọ̀ ni pé nígbà tí à ń sọ̀rọ̀ nípa àlọ́ pípa ọ̀rọ̀ nípa ìṣeré ni à ń sọ yẹn. ìyẹn ni pé bí wọn ṣe máa ń ṣe ìgbékalẹ̀ àlọ́. Ohun tí ó tún ṣe pàtàkì láti tún pe àkíyèsí sí ní ìhín pé àwọn ọ̀nà ìpínsísọ̀rí àlọ́ mìíràn lè wà ní oríṣiríṣi, èyí tí Ọ̀pádọ̀tun (1994) pe àkíyèsí sí lóríṣiríṣi. Ṣùgbọ́n ìdí tí a kò fi fara mọ́ irú àwọn ìpínsísọ̀rí bẹ́ẹ̀ ni pé ìwọ̀nùbọ̀nú

wọn a máa peléke.Èyí tí a ṣe nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí kò fi ààyè sílẹ̀ fún irú ìwọ̀núbọ̀nú bẹ́ẹ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Àjọsepọ̀ wo ni ó wà láàrin àlọ́ àpamọ̀ àti àlọ́ onítàn? Kọ àròkọ kékéré kan láti ṣàlàyé ìdáhùn rẹ.
2. Jíròró lórí àwọn ìpèdè ìṣíde àti ìkádí àlọ́ onitàn láti fi bí wọn ṣe ṣe pàtàkì sí hàn.
3. Ṣe àlàyé ìpínsísọ̀rí àlọ́ onítàn bí ó ti yé ọ pẹ̀lú àpẹẹrẹ méjì méjì fún ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan tí o bá là kalẹ̀.
4. Kín ni àlọ́ onítànwúlò fún?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Àmọ̀rí, A. 1978. *Ìdí Abájọ Kìnnìún*. Manmillan Nigeria Publishers Ltd.,Lagos.

Àpáta, F. O. (Akò mọ ọdún tí wọ́n gbé e jáde) *Àwọn Ìtàn Aládùn*. Ilé Iṣẹ́ Atẹ̀wétà ÌjọbaẸ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìwọ̀ Oòrùn Nàìjíríà, Ìbàdàn.

Babalọlá. A. 1982. *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá: Apá Kìíní*. University Press Limited, Ìbàdàn.

Babalọlá. A. 1985. *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá: Apá Kejì*.: University Press Limited,Ìbàdàn.

Bámgbóṣe, A. 1969 Yorùbá Folktales, *Ìbàdàn*, 6 -12; Àtúntẹ̀-jáde nínú Lawal, N. S., Sadiku, N. O. S àti Dọ̀pámú A. 2000*Understanding Yorùbá Life and Culture*; o. i. 547 – 561,New Jersy.

Ògúnpòlù, B. 1986. "Classification of Yorùbá Prose Narratives", bébà àpilẹ̀kọ tí a kà níbi àpérò lórí ìmọ̀ ìgbé ayé ẹ̀dá láwùjọ Yorùbá (YorùbáFolklore Seminar) ní Yunifásitì Ìpínlẹ̀ Ògùn, Àgọ́ Ìwòyè.

___________1990. "Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Lórí Àlọ́ Àpagbè," nínú Afọlabí Ọlabímtan,"Aáyan Àwọn Ọ̀mọ̀ràn Lórí Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá," o. i. 35 – 56, J. F. Ọdúnj]o memorial Lectures Organisisng Committee, Lagos.

Òjó, O. 1973. *Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yánníbo*. Longman Nigeria Plc., Ìkẹjà. (Àtúntẹ̀ ti 2007.)

Ọ̀pádọ̀tun, Ọ. 1994. *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Y-Books,Ìbàdàn.

# ÌPÍN 2 ÀLỌ́ ONÍTÀN I: KÓKÓ Ọ̀RỌ̀, ÀHUNPỌ̀ÌTÀN, IBÙDÓ ÀTI ÀKÓKÒ ÌTÀN

## ÀKÓÓNÚ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròńgbà
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Kókó Ọ̀rọ̀
4.1.1 Olú Kókó Ọ̀rọ̀: Ìwà Ọmọlúàbí
4.1.1.1 Bíbu Ẹnu Àtẹ́ lu Ìwà Àìdára/Ìkà
4.1.1.2 Yíyònbó Ìwà Dídára/Rere
4.1.2 Kókó Ọ̀rọ̀Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́
4.1.2.1 Ẹ̀san
4.1.2.2 Ìdánwò àti Ìdíje
4.1.2.3 Ìjà Orogún
4.1.2.4 Ìdí Abájọ
4.2 Àhunpọ̀ Ìtàn
4.2.1 Àṣetúnṣe Ìṣẹ̀lẹ̀
4.2.2 Ìṣẹ̀lẹ̀ Àyísódì
4.2.3 Ìrànlọ́wọ́ Àìròtẹ́lẹ̀
4.2.4 Àyípadà Ìgbà
4.2.5 Orin
4.3 Àkókò Ìtàn àti Ibùdó Ìtàn
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

**Àbùdá àlọ́ onítàn mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a yàn láti ṣàlàyé nínú orí yìí. Àwọn** àbùdá àlọ́ onítàn náà ni kókó ọ̀rọ̀, àhunpọ̀ ìtàn, ìbùdó ìtàn àti àkókò ìtàn. Kókó ọ̀rọ̀ ni orí ọ̀rọ̀,òye ọ̀rọ̀ tàbí ẹ̀kọ́ (Ògúndèjì, 1991). Kókó ọ̀rọ̀ inú ẹyọ àlọ́ onítàn kan a máa ju ẹyọ kan ṣoṣo lọ, kí a tó wá sọ ti gbogbo àlọ́ onítàn Yorùbá. Oríṣìí ọ̀nà méjì tí a píngbogbo kókó ọ̀rọ̀ àlọ́ onítàn Yorùbá sí fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wa ni olú kókó àti amúgbá-lẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀. Àwọn mìíràn a tún máa pe olú kókó ọ̀rọ̀ ní lááréjà. Ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúwàbí ni olú kókó ọ̀rọ̀àlọ́ onítàn Yorùbá. Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé gbogboàlọ́ onítàn Yorùbá ni a fi ń dáni-lẹ́kọ̀ọ́ ìwà ọmọlúwàbí.Amúgbá-lẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ ni àwọn kókó ọ̀rọ̀ kékèèké mìíràn tí a fi máa n ṣe àwàgúnlẹ̀ olú kókó ọ̀rọ̀. Nígbà tí olú kókó ọ̀rọ̀ a máa la inú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ kan já, apá kan àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ ni a ti máa ń bá amúgbá-lẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ pàdé; kì í la gbogbo àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ já. Amúgbá-lẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ tàárà ni àwọn ẹ̀kọ́ ìwà pàtó tí ó jẹ yọ nínú àlọ́ onítàn. Gbogbo irú ẹ̀kọ́ ìwà bẹ́ẹ̀ ni ó ń kọni ní ìwà ọmọlúwàbí tí a pè ní olú kókó ọ̀rọ̀àlọ́ Yorùbá ní àpapọ̀. Àwọn

amúgbá-lẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ kan wà tí wọ́n kàn jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ìwà ọmọlúwàbí ni àwọn gan-an kì í ṣe ọ̀rọ̀ nípa ìwà ènìyàn, ṣùgbọ́n wọn a máa jẹ́yọ lemọ́lemọ́ láti inú àlọ́ onítàn kan sí ìkejì. Mòtíìfù ni àwọn onímọ̀ ìtàn àlọ́ máa ń pe irú àwọn amúgbá-lẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀.

Àhunpọ̀ìtàn ni ètò ṣíṣẹ̀ntẹ̀lé ìṣẹ̀lẹ̀ inú lítíréṣọ̀ láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé òpin gẹ́gẹ́ bí a báṣe gbé e kalẹ̀. Àwọn ètò ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwọn àlọ́ onítàn ni àhunpọ̀ìtàn tí a jíròrò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Ìṣẹ̀lẹ̀ kì í ṣẹlẹ̀ láìní àyè tàbí ọ̀gangan ibi tí ó ti ṣẹlẹ̀ àti àkókò tí ó ṣẹlẹ̀. Àkókò ni ìgbà tàbí àsìkò tí ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́ onítàn ṣẹlẹ̀. Ìbáṣepọ̀ máa ń wà láàrin àkókò ìṣẹ̀lẹ̀ àti ibùdó ìtàn inú àlọ́ onítàn. Ibùdó ìtàn ni ibi tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn ti wáyé. Àkókò àt ibùdó ìtàn jọ máań rìn ni.A lè fi wọ́n wé ojú méjì tí owó máa ń ní; wọn kò ṣe é yà sọ́tọ̀ọ̀tọ̀.Bí àlọ́ onítàn ṣe lè bá ìrírí ojú ayé mu náà ni ó lè má bá amu, kí ó jẹ́ mérìíyìírí tàbí kàyéfì, ṣùgbọ́n ti mérìíyìírí tàbí kàyéfì yẹn ni ó hàndé jù nínú àlọ́.Nítorí náà ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn àlọ́, ibùdó ìtàn àti àkókò náà a máa jẹ mọ́ mérìíyìírí.

## 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó ti le ṣàlàyéohun tí olú kókó ọ̀rọ̀ àti amúgbá-lẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ inú àlọ́ onítàn jẹ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ. O ó lèjíròrònípa àwọn àbùdá pàtàkì pàtàkì inú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ onítàn, kí o sì fi àpẹẹrẹ gbe àlàyé rẹ lẹ́sẹ̀. Ní àfikún,ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí oó ti lè ṣàlàyé nípa ìbùdó ìtàn àti àkókò ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́ onítàn, kí o sì lo àpẹẹrẹ tí ó bójú mu fún ṣíṣe àlàyé náà.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ṣé lóòótọ́ ni pé "Irọ́ ní ń jẹ́ àlọ́?" Kọ àrokọṣókí láti ṣàlàyé èrò rẹ
2. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ṣepàtàkì púpọ̀ nínú àlọ́ onítàn. Dárúkọ ohun mejì tí àlọ́ onítàn máa n dá àwọn ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ lé lórí.
3. Kín ni ìwúlò orin nínú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́? Kọ àrokọ ṣókí láti fi ìdáhùn rẹ hàn.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Kókó Ọ̀rọ̀

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìwà ọmọlúàbí ni olú kókó ọ̀rọ̀ inú àlọ́ onítàn gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú. Yorùbá gbà pé ìwà ọmọlúàbí ni àwọn ìwà rere tí ènìyàn gbọ́dọ̀ máa hù ní àwùjọ kí àlàáfíà baà wà láwùjọ. Torí pé àwọn ọmọdé òní ni yóó di àgbàlagbà àti adarí àwùjọ ní ẹ̀yìn ọ̀la, a nílò láti kọ́ wọ́n ní ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí. Kò sí ìwà ọmọlúàbí tí àlọ́ onítàn kò le dá lé. Ó le dá lórí ẹ̀san ìwà rere (bí òtítọ́ ṣíṣe, ríran-ọmọlàkejì lọ́wọ́,ọwọ̀ lílà, àánú ṣíṣe, níní ìtẹ́lọ́rùn, ìforítì,ìrẹ̀lẹ̀, ìtẹríba, ìgbọràn, ìjáramọ́ṣẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ) tàbí ẹ̀san ìwà búburú (bí irọ́ pípa, àgbèrè, olè jíjà, èké ṣíṣe, ọ̀kánjúà, ìrẹ́nijẹ, àbòsí,

àìgbọràn, ìmọtara ẹni nìkan, ìmẹ́lẹ́, ìpànìyàn, ìjọra ẹni lójú, ìgbéraga, ẹnu fífọ́n, ìlara, ilẹ̀ dídà, òfófó ṣíṣe, ọgbọ́n àrékérekè, owú jíjẹ,pàápàá láàrin àwọn orogún, ìrede òru, ìmutípara abbl.)

Àwọn kókó ọ̀rọ̀ amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kan wà tí wọ́n máa ń jẹ yọ lóòrèkóòrè nínú ọ̀pọ̀ àlọ́ onítàn, ṣùgbọ́n àwọn gan-an kì íṣe ìwà gẹ̀gẹ̀ bí a ti ṣo lẹ́ẹ̀kan. Mòtîîfù ni a sọ pé àwọn onímọ̀ àlọ́ onítàn máa ńpè wọ́n. Irú àwọn kókó-ọ̀rọ̀ amúgbá-lẹ̀gbẹ̀ yìíni ìdíje/ ìdánwò,ẹ̀san, ìjà orogúnàtiìdí abájọ.Wọ́n a máalemọ̀lemọ̀ọ̀ nínú àwọn àlọ́ Yorùbá, wọn asì máa ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú ìgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ ọmọlúwàbí lọ́nà tí òye ẹ̀kọ́ ìwà rere tí wọ́n fẹ́ kí àwọn olùgbọ́ àlọ́ máa fi ṣàwòkọ́ṣe, tàbí ìwà burúkú tí wọn kò fẹ́ kí wọ́n fi ṣàwòkọ́ṣe yóò fi yé wọn dáradára.

### 4.1.1 Olú Kókó Ọ̀rọ: Ìwà Ọmọlúàbí

Ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí ni olú kókó ọ̀rọ̀ inú àlọ́ onítàn. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní "Ìwà rere ni ọ̀ṣọ́ ènìyàn, eyín funfun ni ọ̀ṣọ́ ẹ̀rín." Bí ìwà bá nu ọmọ ènìyàn, irú ènìyàn bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń pè ní alàìlẹ́kọ̀ọ́. Láti tọ́ ọmọ bí yóò ṣe máa hùwà rere jẹ́ ìdí pàtàkì kan tí àwọn Yorùbá máa ń fi ń pa àlọ́ onítàn,tó fi ẹ̀kọ́ ìwà rere hàn. Wọn a máa ṣe eléyí nípa mímú kí àwọn ẹ̀dá ìtàn tí ó bá hùwà rere jèrè ìwà dídára wọn nígbẹ̀yìn ọ̀rọ̀, kí ẹni tí ó hùwà búburú náà sì kábàámọ̀ ìwà àìdara rẹ̀ lẹ́yìnọ̀reyìn bákan náà. Wọn kì í sábàá jẹ́ kí ẹni rere kú sí ipò ìkà nínú àlọ́ onítàn. Nítorí náà bí ojú méjì tí owó ń ní ni ọ̀rọ̀ náà. Ìtàn kan náà tí wọn fi ń kọ́ àwọn ọmọdé pé "Ìwà rere ló pé," náà ni wọ́n fi ń kọ́ wọn pé "Ìwà ìkà kò pé." Wọn a máa fi ìdí òwe Yorùbá tí ó sọ pé,bí ó ti wù kí ó pẹ́ tó "Ìkà á ko oníkà, rere á bá ẹni rere" múlẹ̀.Nípasẹ̀ irú àwọn àgbékalẹ̀ báyìí, ọ̀rọ̀ nípa ìforitì, ìfaràdà, ìrètí, akíkanjú, àti ìmúrasíṣẹ́ tí wọ́n jẹ́ ara àbùdá pàtàkì ìwà ọmọlúwàbí a máa jẹ yọ.Ó hàn gbangba pé ọ̀nà méjì gbòógì ni a fi máa ń ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí nínú àlọ́ onítàn. Àwọn ọ̀nà méjì náà ninípa bíbu ẹnu àtẹ́ lú àwọn tí wọ́n hu ìwà ìkà/búuburú/ ibi/ àìdára àti gbígbé oríyìn fún ẹni tí ó hùwà dídára/ rere.

#### 4.1.1.1 Bíbu Ẹnu Àtẹ́ lu Ìwà Àìdára/Ìkà

Bí apàlọ́ bá ti ń pa àlọ́ lọ ni yóò ti máa ṣe àmúlò àwọn àṣàyàn ìlò-èdè tí yóó máa fi hàn pé ìwà àìdára kan ń jẹyọ nínú ìtàn tó ń sọ. Apàlọ́ yóó máa tẹnu mọ́ ìwà burúkú tí ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ hù ní ọ̀nà tó fi jẹ́ pé àwọn ọmọdé yóó ti máa fúnra wọ́n kíyèsi pé àìbójúmu kan jẹyọ. Lẹ́yìn tí ẹ̀dá ìtàn òṣebi bá ti kẹ́san ìwà burúkú rẹ̀, tí apàlọ́ bá ń béèrè ẹ̀kọ́ tí àlọ́ náà kọ́ àwọn ọmọ ni yóò túbọ̀ tẹnu mọ́ ìdí tí ìwà tó jẹyọ nínú ìtàn fi jẹ́ àìdára. Yóò sì kìlọ̀ fún àwọn ọmọdé náà láti jìnnà sí híhu irú ìwà bẹ́ẹ̀. Nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àlọ́ olóníjàpá, a máa ńbu ẹnu àtẹ́ lu àwọn ìwà àìdára gbogbo tí Ìjàpá máa ń hù. Nítorí pé Ìjàpá kì í sábàá sí nídìí ìwà rere ni a fi i máa ń sọ pé "Ọ̀rọ̀ gbogbo kì í sé lórí alábahun." Ó yẹ kí a yán an dáadáa pé nígbà tí Ìjàpà bá mú ìwà burúkú jẹ nígbà míràn, a jẹ́ pé lára

ẹ̀dá ìtàn tí ó ṣe àìdára sí ni a ti fẹ́ kọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ nìyẹn. Àwọn àlọ́ aláìníjàpá náà a máa ni àwọn ìwà búburú tí à ń bu ẹnu àtẹ́ lù. Gbogbo àwọn Ìyáálé tí wọn máa ń gbéraga tí wọ́n sì máa ń fi ayé ni Ìyàwó nínú àwọn àlọ́ onítàn aláìníjàpá olólórogún náà ni àwọn apàlọ́ Yorùbá máa ń bu ẹnu àtẹ́ lù lati kọ́ àwọn ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ pé irú owú jíjẹ tí ó fa ìwà ìkà tí àwọn Ìyáálé náà hù kò dára.

Nínú àlọ́ onítàn aláìníjàpá "Ọmọ tí ó jí irú" (Àpáta, a kò mọ ọdún ìgbéjáde:40), ìwà olè jíjà àti fifi ìtìjú kó àrùn ni apàlọ́ bu ẹnu àtẹ́ lù. Ọmọ kan ní ó jí irú jẹ. Ó sẹ́ jálẹ̀ pé òun kò jí irú jẹ. Ìyá arúgbó tí ó bí àwọn ọmọ mẹ́ta, tí ìkan nínú wọn jí irú jẹ pe àwọn ọmọ náà láti wá búra. Èyí àbíkẹ́yìn tí ó jí irú náà jẹ fi ìtìjú kárùn, kàkà kí ó jẹ́wọ́, ó búra èké, ó sì kú. Bákan náà, ìwà olè jíjà, irọ́ pípa, bíbúra èké, yíya aláìmoore àti jíjẹ́ ọmọ àkúùsin ni apàlọ́ bu ẹnu àtẹ́ lù nínú ìtàn àlọ́ "Awó àti Ìjàpá" (Àpáta, a kò mọ ọdún ìgbéjáde: 46-47). Àwó ṣe òkú ìyá rẹ̀ bí ó ti yẹ ṣùgbọ́n ìjàpá ba òkú ìyá rẹ̀ jẹ́. Ìdí nìyí tí ìyá rẹ̀ fi gbé e ṣépè pé inú ìràwé ni yóó máa sùn títí ọjọ́ ayé rẹ̀. Ọhun patàkì tí wọ́n bu ẹnu àtẹ́ lùnínú ìtàn náà ni àìṣe ẹ̀yìn àwọn òbí dáadáa bó ti tọ́.

### 4.1.1.2 Yíyònbó Ìwà Dídára/ Rere

Lára àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ tó jẹ́ pé ìwà rere ni a máa ń sábàágbọ́ nípa wọ́n ni Ìgbín, nínú àwọn àlọ́ olóníjàpá. Nínú àlọ́ onítàn tí ìjàpá ti kó gbogbo ọgbọ́n ayé sínú akèrèǹgbè, tí ó fẹ́ lọ gbé e kọ́ orí igi kí ẹnikẹ́ni má lè ní àǹfàní sí wọn mọ́, àyàfi òun nìkan, kò lè gún igi náà nítorí àyà ni ó gbé akèrèǹgbè kọ́. Ìgbín tí ó ńkọja lọ nítirẹ̀ ni ó gbà á nímọ̀ràn pé kí ó gbé e kọ́ ẹ̀yìn tí ó fi rí igi náà gùn. Nígbà tí ó gun igi dé okè tán ní ó tó wá yé e pé ènìyàn kan ṣoṣọ kò le dá nígbogbo ọgbọ́n ayé tán. Èyí bí i nínú tó bẹ́ẹ̀ tí ó fi la akèrèǹgbè náà mọ́lẹ̀ láti orí igi. Ìtàn náà kọ́ni pé kí a má fojú di ẹnikẹ́ni, "ọmọdé gbọ́n, àgbà gbọ́, ni a fi dá ilẹ̀ Ifẹ̀," "Ọgbọ́n kò sì pin sọ́dọ̀ ẹnìkan ṣoṣo" Ìgbín, tí ó kéré sí Ìjàpá ní ìrísí, ni ó kọ́ Ìjàpá, tí ó rò pé òún ti kó gbogbo ọgbọ́n ilé ayé jọ lọ́gbọ́n. Nínú ìtàn àlọ́ "Ìgbín pAbuké Ọṣìn," Ìgbín ní oko ńlá tí irè rẹ̀ sì so dáradára nítori ìmúrasíṣẹ́ rẹ̀, ṣùgbọ́n ọ̀lẹ afàjò ni Ìjàpá, tí ó tun jẹ́ àna Ìgbín. Oko rẹ̀ kò ṣe dáradára rará, ó sì ń jowú bàbá ìyàwó rẹ̀. Ní ọjọ́ kan Ìjàpá pa abúké Ọṣìn, tí ó jẹ́ ọba ìlú wọn, ó sì wọ́ òkú rẹ̀ sínú oko àná rẹ̀ tí wọ́n jíjọ pààlà. Òun kan náà ni ó lọ púrọ́ mọ́àna rẹ̀ lọ́dọ̀ ọba pé òun ni ó pa Abuké Ọṣìn àti pé òkú rẹ̀ wà nínú oko Ìgbín. Wọ́n dájọ ikú fún Ìgbín, ṣùgbọ́n ọgbọ́n tí wọ́n dá nípa gbígbé Ìgbín gun ẹṣin ọba tí wọn sì ń kọrin wọ́de káàkiri ìlú pé, wọn óò dá ìgbín lọlá tìtorí pé ó pa Abuké Ọṣìn ló mú kí Ìjápá bọ́sí gbangba láti jẹ́wọ́ pe òun ni òún pa Abúké Ọṣìn náà, pé òun ló yẹ kí ọba dá lọ́la. Bí ọwọ́ṣe tẹ òṣebi nìyí tí a sì dá Ìgbín láre. Àwọn ìwà Ìgbín tí wọn fi kọ́ àwọn ọmọdé lọ́gbọ́n nínú ìtàn kejì yìí ni ìmúrasíṣẹ́, ìṣòótọ́, ìfẹ́ àiṣẹ̀tàn, ìfaradà àti ọgbọ́n inú. Nínú àwọn àlọ́ méjèèjì yìí, kò sí àní àní pé Ìgbín ni wọ́n fi ṣe àwòkọ́ṣe ìwà rere. [Wo Babalọlá 1973: àti 1979: fún ẹ̀dà àwọn àlọ́ olóníjàpá méjèèjì wọ̀nyí].Nínú àwọn àlọ́ onítàn aláìníjàpá olólórogún

àwọn Ìyàwó tí a pọ́n lójú, ṣùgbọ́n tí wọn fara da ìṣoro, tí ọ̀rọ̀ wọn sì já sí ayọ̀ lẹ́yìnọ̀rẹyìn ni a fi parokò ìwà rere.

Ní inú àlọ́ onítàn"Àṣá kì í Jalè"(Fújà, 1969: 88 – 92), apàlọ́ sọ ìtàn ìdí abájọ tí àṣá fi ń gbé adìyẹ, pé kì í ṣe olè ni ó ń jà.Orogún Ìyá Aláǹtéré ni ó dẹ́jàá èèwọ̀ ọmọ náà láti fi dá Ìyáálé rẹ̀ lóró. Ó rán Aláǹtéré lódò, Olúwẹri sì gbé ọmọ náà ní torí èèwọ̀ tí wọ́n ti bà jẹ́. Ọ̀dọ̀ olúwẹri ni wọ́n ti tọrọ ọmọ náà nígbà tí ojú ọmọ ń pọ́n Bàbá Aláǹtéré, kí ó tó fẹ́ ìyàwó tuntun. Bí gbogbo ènìyàn ati àwọn alágbara ti gbìyànjú tó wọn kò rí Aláǹtéré gbà padà lọ́wọ́ Olúwẹri. Àṣá ni ó bá wọn gba ọmọ náà padà lẹ́yìnọ̀rẹyìn. Àdéhùn tí ó sì bá Bàbá Aláǹtéré ṣe ni pé yóò máa fún òun ní òròmọdìẹ tí òún bá ti wá. Nítorí náà nǹkan àdéhùn ni òròmọdìẹ tí àṣá ń gbé, kì í ṣe olè ni ó jà. Bí kò bá sí ìrànlọ́wọ́ tí àṣá ṣe fún àwọn òbí Aláǹtéré, ọ̀dọ̀ Olúwẹri ni ọmọ náà kò bá gbé sí. Ohun tí ìtàn yìí fi kọ́ àwọn ọmọdé ni ìwà ìranra-ẹni-lọ́wọ́ àti fífi ẹ̀mí ìmoore hàn sí ẹni tó bá ṣe oore fúnni. Bákan náà ni ìtàn ọmọ tí ó ran ìlú rẹ̀ lọ́wọ́ láti pa ẹ̀kùn tó ń pa àwọn ará ìlú jẹ, tí ọba dá lọ́lá nínú ìtàn "Ọmọ kan àti àwọn òbí rẹ̀" (Ọ̀pádọ̀tun, 1994:41-42). Ọmọ yìí kò fi ti pípẹ̀gàn tí wọ́n pẹ̀gàn rẹ̀ ṣe nígbà tí ó yan iṣẹ́ ọdẹ láàyò láàrin àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí àwọn òbí rẹ̀ bí, ó fi ẹ̀mí ara rẹ̀ wéwu, ó ṣe oore mánigbàgbé fún ìlú rẹ̀, ó sì kó èrè ìrànlọ́wọ́ tí ó ṣe fún ìlú rẹ̀.

### 4.1.2 Kókó Ọ̀rọ̀ Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́

Nígbà tí olú kókó ọ̀rọ̀ àlọ́ jẹ́ ìwà ọmọlúàbí, oríṣiríṣi ìwà pàtó tí ènìyàn lè hù láti jẹ́ ọmọlúàbí àti ìwà tí ènìyàn lè hù tí ó le má jẹ́ kí ènìyàn jẹ́ ọmọlúàbí ni àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ tààrà inú ìtàn àlọ́. Ìgbékalẹ̀ irú àwọn ìhùwàsí wọ̀nyí ni ó máá ń ṣe àfihàn kókó ọ̀rọ̀ ìwà ọmọlúwàbí gẹ́gẹ́ bí a ti sọ tẹ́lẹ̀. Lọ́rọ̀ kan àwọn kókó ọ̀rọ̀ amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ pàtó (ìwà rere àti ìwa búburú) wọ̀nyí ni wọ́n máa ń fi ṣe ìgbékalẹ̀ olú kókó ọ̀rọ̀ ìwà ọmọlúwàbí ní gbogbogbòò.

Ní gbogbo ìgbà ni ó máa ńfẹ́rẹ̀ jẹ́ wí pé láti fìdí kókó ọ̀rọ̀ ọmọlúwàbí múlẹ̀ danindanin nínú àlọ́ onítàn kan, àtìwà rere àtìwà burúkú ni ó jìjọ máa ń péjúpésẹ̀ sínú àlọ́ onítànkọ̀ọ̀kan. Ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ àbùdá òníbejì alójú–lódì ni èyí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kókó ọ̀rọ̀ ìwà rere lòdì sí ti ìwà burúkú síbẹ̀ nínú àlọ́ wọ́n jìjọ máa ń rìn ni láti ṣe àwàgúnlẹ̀ ìwà ọmọlúwàbí dáradára. Nípasẹ̀ ìwà àidárá tí ẹni tí óbá hùwà àidára hù ni ìwà dídára ẹni tí ó bá hùwà dídára yóò ṣe hàn ketekete. Bí a bá ṣe àkíyèsí dáadáá a ó rí i pé bí ọ̀rọ̀ ti rí nìyí nínú gbogbo àwọn àpẹẹrẹ tí a ti ṣe sẹ́yìn.Nínú ìtàn àlọ́ "Ìgbín pAbuké Ọṣìn," tí a ti tọ́ka sí ṣajú, a ó rí i pé ìwà rere Ìgbín ni ó jẹ́ kí ìwà ìkà àti òdóro Ìjápá hàn ketekete. Gbogbo àwọn ìwà rere àti ìwà búbúrú tí ènìyàn lè hù láwùjọ tí a sì ti dárúkọ díẹ̀ nínú wọn sẹ́yìn ni wọ́n lè súyọ nínú àlọ́ onítàn gẹ́gẹ́ bí i amúgbálẹ́gbẹ̀ kókó ọ̀rọ̀. A ti ṣe àgbéyẹ̀wò àti àpẹẹrẹ díẹ̀ nínú àgbékalẹ̀ àwọn ìwà wọ̀nyí sẹ́yìn.

Nítorí náà àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ ti a tún pè ní mòtíìfù ni a óò gbé yẹ̀wò báyìí. Àwọn náà niẸ̀san,ìdíje/ ìdánwò,ìjà orogúnàti ìdí abájọ.

### 4.1.2.1 Ẹ̀san

Yorùbá kò fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ọ̀rọ̀ ẹ̀sàn. Wọ́n a máa sọ nípa ẹ̀san pé, "Ohun gbogbo ló ní ẹ̀sàn/ èrè." Wọ́n tún gbà pé, "Ènìyàn tó ṣu sọ́nà lálọ, yóò bá eṣinṣin lọ́nà lábọ̀." Wọn a máa sọ pé, "Igbá tí a bá fi wínkà ni a fi í san án," "Bí ènìyàn bá da omi síwáju, olúwarẹ̀ yóò tẹlẹ̀ tútù,""ẹni tí ó bá da eérú ni eérú máa ń tọ̀," àti pé "Ẹ̀san ò gbóògùn,""Àgbà tó bá sì gbin èèbù ìkà, orí ọmọ rẹ̀ ni yóò hù lé." Ọ̀kan nínú ọ̀rọ̀ ẹnu Yorùbá tí a máa ń sábàá fi ṣe àkàwé ọ̀rọ̀ ẹ̀san nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá ni:

Ẹni tó ń ṣe rere kó múra síre
Ènìyàn tó ń ṣèkà kó múra síkà
Àtoore àtìkà, ọ̀kan kì í gbé

Gẹ́gẹ́ bí ati sọ tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀,olúkálùkù àwọn ẹ̀dá ìtàn ní í máa kó èésú ìwà wọn tí wọ́n bá hù nínú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ onítàn. Láti fi àwọn ẹ̀kọ́ inú àwọn ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ Yorùbá yìí kọ́ àwọn ọmọdé ni àwọn òbí/àgbàlagbà àwùjọ máa ń fi pa oríṣìíríṣìí àlọ́ onítàn Yorùbá tó dá lé orí kókó ọ̀rọ̀ ẹ̀san. Ṣàṣà ni àlọ́ onítàn Yorùba tí kì í ní mòtíìfù ẹ̀san nínú. Bí apàlọ́ bá ti ń pa àlọ́ ni yóò ti máa fi ìlò èdè rẹ̀ pàkíyèsí àwọn ọmọdé sí ìwà àìdára tàbí dídára tí ẹ̀dá ìtàn àlọ́ kan ń hù, tí àwọn ọmọdé yóò sì ti máa nírètí ẹ̀san tí yóò jẹ́ àyọrísí ìwà búburú tàbí rere bẹ́ẹ̀. Nígbà mìíràn, a lè rí ọmọdé tí yóò fẹ́ béèrè ohun tí wọ́n fi ẹni tí ó hùwà burúkú náà ṣe lásìkò tí àlọ́ ń lọ lọ́wọ́. Ojúṣe apàlọ́ tó dáńtọ́ ni láti lo ọgbọ́n ìkóniláyàsókè, kí ó sì tẹ̀ síwájú nínú ìtàn rẹ̀, kí ó má bà di pé ní àárín ìtàn ni àwọn ọmọdé náà yóó ti mọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀ lópin ìtàn àlọ́. Sísọ abala àhùnpọ̀ ìtàn tí ẹ̀dá ìtàn àlọ́ òṣebi ti hùwà ibi rẹ̀ ní àsọtúnsọ tàbí ṣíṣe àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan ní àṣetúnṣe jẹ́ ète láti tẹnu mọ́ ìwà rere tàbí búburú tí ẹ̀dá ìtàn kan hù, èyí tí yóò yọrí sí àtúnbọ̀tán tí ó bá òdiwọ̀n ìwà tó hù mu gẹ́lẹ́. Nítorí náà méjì ni ẹ̀san ìwà tí ẹ̀dá ìtàn hù le jẹ́ nínú àlọ́ onítàn ní ìbámu pẹ̀lú irú ìwà rẹ̀; yálà ẹ̀san rere, fún ìwà rere, tàbí ẹ̀san búrúkú, fún ìwà burúkú. Ẹ̀san ìwà rere nínú àlọ́ le jẹ́ ìdánilọ́lá tàbí gbígbéniga-sípò-ọlá, fífúnni-lẹ́bùn-owó tàbí dúkìá, (bí ikí ọba dá ilé àti ọ̀nà rẹ̀ sí méjì, kí ó kó apá kan fún ẹni tí ó ṣe rere), fífúnni-níyàwó, fífinijoyè ìlú (bí i sísọni digbákejì ọba) tàbí fífinijọba pàápàá, dídániláre, tàbí òmíràn.

Àpẹẹrẹ ẹ̀san níbi tí a ti kẹ́san ìwà rere fún ẹ̀dá ìtàn àlọ́ aṣerere ni ìtàn "Arìẹgẹ," èyí tí àkùkọ fi ṣe aya lẹ́yìn tí ó ṣe ipò kìn-ín-ní nínú ìdíje oko-ríro tí òun àti àwọn ẹranko tí wọ́n jọ ń du Arìẹgẹ ṣe (Apata, a kò mọ ọdún ìgbéjáde: 27 – 29). Bákan náà ni ìtàn "Pankoko" tí ìyá rẹ̀ yọ́ fi sílẹ̀ sá lọ sí ilú òkèèrè nítorí ó burẹ́wà, ṣùgbọ́n tí ó padà di ọba ìlútí ìyá rẹ̀ sá lọ náà tórí pé ó forí ti ìṣòro rẹ̀. Ẹ̀san ìwà burúkú le jẹ́ ẹ̀bi ikú (bíbẹ́nilórí tàbí títi-ojú-ẹni-yọdà-lákọ̀, kí wọ́n sì tẹ̀yìn ẹni kì í bọ̀ ọ́), lílénikúrònílùú,

sísọnidẹniyẹpẹrẹ, gbígbẹ̀san-lọ́wọ́-ẹni, fífiniṣẹlẹ́yà, yíyọni-nípò ọlá tàbí àṣẹ, pípàdánù dúkìá, kíkọ ìyàwó/ọkọsílẹ̀, fífúnni-níṣẹ́-tó-le-ṣe àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ìtàn "Ìjàpá, ìgbín àti Abuké Ọṣìn" (Babalọlá, 1983: 103-106) jẹ́ àpẹẹrẹ àlọ́ tí ẹ̀dá ìtàn òṣebí (Ìjàpá) ti kẹ́san ìwà ìpànìyàn àti àkóbá tí ó hù (wọ́n tojú rẹ̀ yọdà, wọ́n sì ti ẹ̀yìn rẹ̀ kí í bọ̀ ọ́). Àpẹẹrẹ mìíràn ni bí Ìjàpá ṣe kẹ́san ìwà ṣìṣègbè lẹ́yìn ọ̀kẹ́rẹ́ lásìkò tí ọ̀kẹ́rẹ́ àti asín ń jà lọ́jà, èyí tó sọ imú Ìjàpá di kánńbó títí di òní (Babalọlá, 1973: 122 – 124). Bákan náà ni ọ̀rọ̀ rí nínú àwọn àlọ́ onítàn aláìníjàpá olólórogún tí a ti tọ́ka sí àwọn Ìyálé tí wọ́n hùwà àìdára jèrè ìwà àìdára wọn nígbà tí àwọn Ìyàwó tí wọ́n jìyà,ṣùgbọ́n tí wọ́n ní ìforítì àti ìfaradà, náà gba ẹ̀san rere tiwọn náà bí ati fi hàn tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀. Ó wá hàn gbangba pé ẹ̀san gẹ́gẹ́ bí i kókó ọ̀rọ̀ amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ máa ń fìdí ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúwàbí múlẹ̀ ni. Lọ́nà míràn a lè sọ pé iṣẹ́ tí ẹ̀san gẹ́gẹ́ bí àmúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ (tàbí mòtíìfù) ń ṣe ni ìgbélárúgẹ ìwà rere tàbí yíyọ̀nbó ìwà ọmọlúwàbí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé gbogbo ìyókù àhunpọ̀ ìtàn láti ìbẹ̀rẹ̀ ni í máa tọ́ka sí irú ẹ̀san tí olúkúlùkù yóò gbà, síbẹ̀ ibi ìparí tàbí ìgúnlẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn ni ọ̀rọ̀ ẹ̀san tí tó máa ń hànde gbangba gbàǹgbà.

## 4.1.2.2 Ìdánwò àti Ìdíje

Ìdánwò àti ìdíje náà jẹ́ kókóọ̀rọ̀ amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ tàbí mòtíìfùkan tí ó máa ń jẹyọ nínú àlọ́ onítàn Yorùbá dáradára. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ló jẹ́ pé olórí ìlú, alágbára kan tàbí ẹ̀dá ìtàn òṣebi kan ló máa ń gbé ìdánwò ka iwájúolú ẹ̀dá ìtàn. Àbùdá kan pàtàkì tí ó sábà máa ń ya àwọn tí a gbé ìdánwò fún sọ́tọ̀ sí àwọn tí ó gbé ìdánwò fún wọn ni wíwà ni ipò àìlágbára. Irú ẹ̀dá ìtàn bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ ọmọ òrukàn, ọmọ tálákà, Ìyàwó nínú àwọn ìtàn olólórogún, ó sì le jẹ́ ọmọdé. Ìdánwò tí a máa ń gbé fún wọn máa ń le ju ohun tí agbára wọn ká lọ ṣùgbọ́n láti ipasẹ̀ ìrànlọ́wọ́ àìròtẹ́lẹ̀ kan tàbí òmíràn tí wọ́n rí gbà láti ọ̀dọ̀ òkú ọ̀run wọn, tàbí ẹ̀dá abàmì kan ni àwọn ìdánwò yìí ṣe máa ń ṣe é ṣe. Lára ìdánwò tí a le gbé fún ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ni dídá ọba mọ̀. Èyí jẹyọ nínú ìtàn àlọ́ 'Àdíjátù Kẹkẹlúkẹ.' Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Adíjátùyege nínú ìdánwò àkọ́kọ́, tó pa àwọn ìjòyè àti ọba láyò ọlọ́pọ́n tí wọ́n ń ta nínú àfin lọ́jọ́ tí orogún ìyá rẹ̀  rán an kí ó lọ fọnná wá níbẹ̀, tí ó sì lẹ́tọ̀ọ́ sí ìdánilọ́la tí ọbá ti ṣe ìlérí rẹ̀, síbẹ̀ ọbá tún gbé ìdánwò míràn sí iwájú rẹ̀, wí pé tí ó bá lè dá òun, ọba, mọ̀ lẹ́yìn ọjọ́ mejé ni òun óò tó ó mú ìlérí náà ṣé fún un. Nínú àlọ́ yìí ọba ti yira padà, ó múra bí i tálákà.

Bíkò bá sí ìránlọ́wọ́ tí ọmọ náà rí gbà láti ọ̀dọ̀ ìyá rẹ̀ tí ó ti kú, ṣùgbọ́n tí ó di ẹyẹ tí ó sì ń kọrin láti jẹ́ kí Àdíjátù mọ̀ pé ọba ni ẹni tí ó gbékun lémú, tí ó sì wẹ̀wù àkísà, kì bá tí yege nínú ìdánwò náà. Nígba tíÀdíjátù sì yege, tí ó dá ọba mọ̀, ọba níláti mú ìlérí rẹ̀ ṣẹ, ó pín ilé àti ọ̀nà rẹ̀ sí méjì, ó sì kó ìlàjì fún un. Àpẹẹrẹ mìíràn tún ni àwọn ọmọdé méta tó ń ṣeré, nínú àlọ́ onítàn 'Ọmọdé méta n ṣeré.'Ọ̀kan nínú wọn sọ pé òun le gun igi àgbọn lái lo igbà, èkejì sọ pé òún lè ta ọ̀run lọ́fà, ẹ̀kẹta ní òun le

wẹ omí òkun já. Nígbà tí Ìjàpá, oníkèéta ẹ̀dá sún ọ̀rọ̀ náà sí etí ọba, ọ̀rọ̀ náàkúrò ní eré, ó di ìdánwò tí a gbé fún àwọn ọmọ náà ṣe tí wọ́n sì gbọdọ̀ yege ninú rẹ̀ tí wọn kò bá fẹ́ kú; ṣùgbọ́n pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ òkú ọ̀run wọn, gbogbo ìlérí wọn yìí di ṣíṣe.

Ìdíje nínú àlọ́ onítàn yàtọ̀ díẹ̀ sí ìdánwò. Ìdánwò tí a gbé kalẹ̀ láti mọ ẹni tí yóò ṣe ìpò kìn-ín-ní, tí ohun tí a torí rẹ̀ díje yóò sì já mọ́ lọ́wọ́ ni ìdíje. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, àwọn tí ó bá dá ara wọn lójú ni ó sábàá máa ń kópa nínú irúfẹ́ ìdíje bẹ́ẹ̀. Ìdíje lè pa ẹ̀dá ìtàn méjì péré pọ̀, wọ́n sì lè ju méjì lọ.

Ìdíje lèwáyé bí ìpèníjà láàrin àwọn ẹ̀dá ìtàn nígbàmíràn. Ọ̀kan nínú àwọn olùdíje yóò gbẹ̀yẹ lọ́wọ́ àwọn adíje yòókù torí pé ó lo ọgbọ́n orí tàbí ó rí ìrànlọ́wọ́ òjijì gbà lọ́wọ́ ẹ̀dá ìtàn àlọ́ mérìíyìírí bí òkú ọ̀run, àlùjọ̀nnú, ọ̀rọ̀ àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Nígbà mìíran gbígba ẹ̀yẹ lọ́wọ́ àwọn adíje yòókù le jẹ́ ẹ̀san jíjáramọ́ṣẹ́, òtítọ́ ṣíṣe, àìṣẹ̀tàn tàbí ṣíṣe kóńgẹ́ ire. Àpẹẹrẹ ìdíje nínú ìtàn àlọ́ ni ìtàn “Abahun àti Ẹ̀lulùú” (Apata, a kò mọ ọdún ìgbéjáde: 52-53) tí wọ́n jìjọ díje láti fẹ́ Ìgè, ọmọ ọba. Àpẹẹrẹ mìíràn ni ìtàn “Ìjàpá àti Àkókó” tí wọ́n jọ díje láti fẹ́ Sebeje, ọmọbìnrin arẹwà, tí baba ọmọ náà gbé ìdánwò oko ríro fún wọ́n pé ẹni tó bá lágbára jùlọ ni ọmọ náà yóò fẹ́ (Babalọlá, 1982:125-129). Nínú àlọ́ kìn-ín-ní, Ìjàpá rí ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ lò fún ẹ̀lúlùú, ó sì fẹ́ Ìgè mọ́ ọn lọ́wọ́. Ṣùgbọ́n nínú àlọ́ kejì, Àkókó fi ọ̀rọ̀ lọ àwọn àgbà, ó sì jèrè ìwà àìṣèmẹ́lẹ́ rẹ̀ torí tí ó la alábahun àti olùrànlọ́wọ́ rẹ̀ (ẹfọ̀n) nínú ìdíje oko ríro tí wọ́n jọ ṣe. Àkókó ni Sebeje já mọ́ lọ́wọ́.

Nínú àlọ́ onítàn “Ìjà láàrín Ìjàpá àti Erin,” (Babalọla 1975: 22- 27), Ìjàpá ni ó ń fọ́nnu pé òun lè lu Erin tí ọ̀rọ̀ bá di ibi ìjà. Nígbà tí Ọba gbọ́, ófi àṣẹ sí ìdíje ìjà náà, jàpá sì lo ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ rẹ̀ láti ṣẹ́gun. Bákan náà ni ọ̀rọ̀ rí nínú àlọ́ onítàn ìdíje eré sísá láàrin “Ọ̀pọ̀lọ́ àti Ẹfọ̀n,” Ọ̀pọ̀lọ́ ni ó pe Ẹfọ̀n níjà pé òun yára nínú eré sísá jù ú lọ. Ẹfọ̀n fojú tẹ́ńbẹ́lú Ọ̀pọ̀lọ́ tìgbéraga tìgbéraga, ṣùgbọ́n ẹ̀tẹ́ ni ó bá bọ̀ nídìí rẹ̀ nítorí pé Ọ̀pọ̀lọ́ lo ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ fún un ó sì gbẹyẹ lọ́wọ́ rẹ̀ nínú ìdíje ere sísá náà. Ìtìjú èyí ló mú Ẹfọ̀n sá kúrò ní ìlú tí ó ń lọ gbé ọdàn láti ọjọ́ náà. Lóòótọ́ ni pé ìgbéraga a máa ṣíwájú ìparun.

Ohun kan tí a níláti kíyèsí nípa amúgbá-lẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ (tàbí mòtíìfù) ìdíje gẹ́gẹ́ bí i ti ẹ̀san náà ni pé ó máa ń ṣèrànwọ́ láti fẹsẹ̀ kókó ọ̀rọ̀ múlẹ̀ ìwà kan tàbí ìkejì múlẹ̀ ni. Nípasẹ̀ ìdánwò tàbí ìdíje oríṣiríṣi tí ó bá wáyé ni àṣejù oníṣẹ́ ibi máa ń hàn ketekete tí sùúrù, ìforítì, ìfàyàrán-ìṣoro, àti ìfaradà ẹni rere sì máa ń jẹ jáde gbangba. È yí ni kì í jẹ́ kí ẹsán tí oníkálùkù bá wá gbà lẹ́yìnọ̀rẹyìn ó yàni lẹ́nu. Nígbà tí ó jẹ́ pé ibi ìgúnlẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn ni €ẹ̀san ti máa fara hàn àárín àhunpọ̀ ìtàn ni ìdánwo àti ìdíje ti máa ń súyọ.

## 4.1.2.3 Ìjà Orogún

Ògúndèjì (1991) ṣàlàyé bí ọ̀rọ̀ orogún ṣe jẹ́ kókó kan gbòógì nínú àlọ́ onítàn Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí atisọnínú ìpín àkọ́kọ́ módù kẹtà yìí, Ọ̀pádọ̀tun (1994) náà ní ìsọ̀rí àlọ́ onítàn tí ó pè ní olórogún àti àlọ́ onítàn aláìlórogún. Kíyèsí pé olólórogún àti àláìjólórogún ni àwa pè é láti mú pọ́n-ọ́n-na kékéré tí ówà nínú bí Ọ̀pádọ̀tun ṣe pèé kúrò ni ó fa ìyàtọ̀ náà.

A ti ṣàlàyé àti àpẹẹrẹ nípa àlọ́ olólórogún ní ìpín kìn-ín-ní módù yìí. Kò sí àní àní pé pàtàkì ni ọ̀rọ̀ orogún nínú àlọ́ onítàn, ìdí nìyí tí a fi lò ó bí òdiwọ̀n ìpínsísọ̀rí wa.Ohun tí Yorùbá fi káràmásìkí ọ̀rọ̀ orogún, tí wọ́n sìṣe máa ń lò láti kọ́ àwọn ọmọ wọn níwà ọmọlúàbí láti ìgbà èwe wọn ni pé, àwùjọ oníyàwó púpọ̀ ni àwùjọ Yorùbá ní ayé àwọn baba wa, tí à sọ yìí. Ojú kan náà, tàbí kí á sọ pé inú ilé kan náà ni àwọn orogún àti àwọn ọmọ wọn jìjọ máa ń gbé. Láti pe àkíyèsí àwọn ọmọ sí irú ìbágbépọ̀ báyìí láti kékeré wọn; kí wọ́n lè mọ bí à, á ṣe é hùwà fún ìbágbépọ̀ tí ó mọ́yán lórí láàrin ẹ̀ẹ̀dẹ̀ tàbí agboolé ni irú àwọ àlọ́ náà wà fún.Nípasẹ̀ àwọn àlọ́ onítàn olólórogún yẹn ni wọ́n fi ń pe àkíyèsí àwọn ọmodé sí i wí pé ẹ̀yìn ẹni tí kò fi ìfẹ́ àti òótọ́ inú bá orogún rẹ̀ lò kì í dára, ṣùgbọ́n ẹni tí ó fi ìfẹ́ àti àiṣẹ̀tàn lò, bí ó tilẹ̀ rí ìṣoro, ìgbẹ̀yìn rẹ̀ yóò dára púpọ̀púpọ̀ kọjá ìṣoro tí óní ṣaájú lọ. Nípa báyìí ni àwọn Yorùbá fi máa ń gbin èèbù ìwà rere sínú àwọn ọmọ̣dé láti pínníṣín wọn, tí wọ́n sì tún fi ń jẹ́ kí àwọn ọmọ náà mọ irú ewu tí ó wà ní àyíká wọn nípasẹ̀ ìdílé olórogún, kí wọ́n lè máa ṣọ́ra ṣe.

Ọ̀nà méjì tía máa ń gbà fi orogún hàn nínú àlọ́ onítàn bí ó ṣe jẹyọ nínú àlàyé wa yìí àti àwọn àpẹẹrẹ tí a ti ṣe ṣẹ́yìn ni: gẹ́gẹ́ bí ènìyàn rereàti gẹ́gẹ́ bí ènìyàn búburú. Bí àwọn àpẹẹrẹ tí a ti fi hàn ṣe gbé e kalẹ̀ Ìyáálé ní a máa ń sábàá fi hàn nínú àwọn àlọ́ onítàn olólórogún gẹ́gẹ́òṣebi, tí Ìyàwó sì máa ńsábàá jẹ́ ẹni rere (aṣerere àti òjìyà).Ní ìgbà míràn a lè rí Ìyàwó òṣebi náà, pàápàá nígbà tí Ìyáálé kò bá sí ní ilé tàbí tí kò bá tilẹ̀ sí ní ìdí 'ẹrù' rẹ̀ mọ́, nítorí ìdí kán tàbí òmíràn. Àpẹẹrẹ àlọ́ onítàn Yorùbá kan níbi tí a ti fi Ìyàwó hàn gẹ́gẹ́ bí òṣebini bí ìyáwó ẹ̀yìn ìyá Aláǹtéré ṣe rán an lọ sọdò lọ pọnmi lẹ̀yìn tí wọ́n ti ṣàlàyé fún un pé èèwọ̀ ọmọ náà ni pé kò gbọdọ̀ ṣe iṣẹ́ kankan, kí á tó wá sọ ti lílọ sódò lọ pọnmi(Fuja 1967: 88 – 93).

Ìbéèrè tí kò lè ṣalàì jẹyọ ni pé, kín ni ìdí tí Ìyáálé fi máa ń sábàá jẹ́ òṣebi nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá? Ìdí ni pé nínú àṣà Yorùbá, ìyáálé ni àgbà nítorí pé òun ni ọkọ kọ́kọ́ fẹ́ wọlé, òun ni ó ní àṣẹ àti agbára lórí ìyàwó tí a fẹ́ tẹ̀lé e. Lára ojúṣe ìyàwó, sì ni kí ó máa bọ̀wọ̀ fún ìyáálé rẹ̀, kí ó sì máa gbọ́ràn sí i lẹ́nu. Àǹfàní yìí ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìyáálé máa ń lò láti jẹ gaba lé ìyàwó wọn lórí nítorí owú jíjẹ. Ọkọ ní ìgbà míràn, a máa fìfẹ́ hàn sí ìyàwó ju ìyáálé lọ paàápàá tí ó bá mú un ní ààyọ rẹ̀. Èyí ni hulẹ̀húlẹ̀ ohun tí í máa ń fa owú jù lọ láàrin ẹ̀ẹ̀dẹ̀ jù lọ.

Ohun kan tí a níláti rántí pe àkíyèsí sí kí a tó kúrò ní ìpín yìí ni péorógún ṣíṣe láàrin ẹ̀dẹ̀, bí a ti gbé e kalẹ̀ nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àlọ́ onítàn wà láti bu ẹnu àtẹ́ lu owú jíjẹ tí í fa àrankàn, ìlara, odì yíyàn, ìdira-ẹni-sínú, àìnífẹ̀ẹ́ àti àwọn ìwà ìkà míràn, tí í sì í máa da ẹbí rú. Nítorí náà ni òun náà ṣe jẹ́ àmúgbákẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ tàbí mòtíifùtí ó ń fi ẹ̀ṣẹ̀ ẹ̀kọ́ ìwà rere múlẹ̀ láàrín ìdílé. Kì í ṣe èdè-àìyedè tàbí ìpórógan láàrín ẹbí gan-an ni wọ́n fẹ́fi àwọn ọ̀wọ́ àlọ́ onítàn bẹ́ẹ̀ gbé lárúgẹ. Kì í sì í ṣe pé wọ́n fẹ́ fi àwọn ọ̀wọ́ àlọ́ náà bu ẹnu àtẹ́ lu níní ìyàwó ju ẹyọ kan lọ. Ó yẹ kí á pe àkíyèsí sí i pé ìjàOrógún gẹ́gẹ́ bí amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ tàbí mòtíìfù a máa lá gbogbo inú àhunpọ̀ ìtàn já ní tirẹ̀. Ó fi èyí yàtọ̀ sí àwọn mótíìfù yókù. Ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí àlàyé wa kì í ṣe ìwà tí a fẹ kí àwọn ọmọdé kọ́ ẹ̀ kọ́ nípa rẹ̀, ak]an ṣe ìmúlò rẹ̀ láti gbé ọ̀òye ẹ̀kọ́ nípa bí ó ṣe yẹ kí á máa hùwà nínú ẹbi kalẹ̀ ni. [‘O hàn gbangba pé ó wà fún ṣíṣe àwàgúlẹ̀ kókó ọ̀rọ̀ ìwà ọmọlúwàbí láàrin ẹ̀ẹ̀dẹ̀ ni.

### 4.1.2.4 Ìdí Abájọ

Kókó ọ̀rọ̀ amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ tàbí mòtíìfùmìíràn tí ó máa ń jẹ yọ nínú ọ̀wọ́ àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá kan ni síso ìdí abájọ. Ọ̀pádọ̀tun (1994) tilẹ̀ ní ìsọ̀rí àlọ́ onítàn asọdí abájọ àti àlọ́ onítàn aláìsọ̀dí abájọ. Àlọ́ onítàn tí a fi ń sọ ìdí tí ohun kan fi rí bí óṣe rí lónìí ni wọ́n ní kókó ọ̀rọ̀ àmúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ tàbí mòtíìfù yí nínú. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìwà kan tàbí òmíràn a tún maa so pọ̀ mọ́ọ̀rọ̀ ìdí abájọ náà ni a fi rí ti ìdí abájọ yẹn bí àmúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ tàbí mòtíìfù.Lóòtọ́ ni pé ó máa ń sábàá jẹ jáde láti inú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àhunpọ̀ ìtàn, ṣùgbọ́n ìparí àhunpọ̀ ìtàn ni ó ti máa hàn gbangba. Ó máa ń sábàá jẹ́ pé láti inú àtúnbọ̀tán tàbí èrè /ẹsan ìwà tí ẹ̀dá ìtàn kan bá hù ni ìdí abájọ náà ti máa ń sú yọ. Pàtàkì iṣẹ́ tí àwọn Yorùbá máa ń fi amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ tàbí mòtíìfù ìdíabájọ jẹ́ nínú àlọ́ onítàn pípa ni pípe àkíyèsí àwọn ọmọdé sí ìrísí oríṣiríṣi nǹkan ní àyíká wọn láti pínníṣín wọn, kí wọ́n lè máa dá wọn mọ̀ yàtọ̀ sí ara wọn. Láti pe àkíyèsí sí bí ẹ̀yìn ìjàpá ṣe rí ni ìdí abájọbí ẹ̀yìn Ìjàpá ṣe rígbọ́ngungbọ̀ngun wàfún nínú àwọn àlọ́ olóníjàpá kan.Láti pe àkíyèsí sí i wí pé ọrùn ẹyẹ ògòǹgò gùn ni wọ́n ṣe pa àlọ́ ‘Ìdí tí Ọrùn Ògòǹgò fi Gùn’. Bákan náà ni wí pé wọ́n fẹ́ pe àkíyèsí sí àbùdá àdání pàtàkì tí ó ya ẹyẹ igúnnugún ṣọ̀tọ̀ láàrín àwọn ẹyẹ yòókù ni wọn fi mú ọ̀rọ̀ bí orí ẹyẹ náà ṣe pá wọ inu àlọ́ onítàn tí ó ti jẹ jáde.

Nípasẹ̀ àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni àwọn ọmọdé fi máa ń kẹ́kọ̀ọ́ nípa ṣiṣe ìdámọ̀ púpọ̀ nínú àwọn ẹranko, ẹyẹ, kòkòrò àti ohun mìíràn gbogbo tí ńbẹ láwùjọ. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àlọ́ tí a fi sọ ìdí abájọ náà ni a tún ti fi ẹ̀kọ́ ìwà kan tàbí òmíràn múlẹ̀. Ọgbọ́n pípa àlọ́, tí ó jẹ́ àròbájọ báyìí, tí ó kún fún ìṣẹ̀lẹ̀ kàyéfì, ajọnilójú, tí ó kàmọ̀mọ̀, tàbí kí á kúkú sọ pé tí ó kún fún ìṣẹ̀lẹ̀ àti ẹ̀dá ìtàn mérìíyìírí ni wọ́n fi máa ń mú ọkàn àwọn ọmọdé mọ́lẹ̀ láti kọ́ wọn ní ẹ̀kọ́ nípa àyíká wọn àti ìwà ìṣẹ̀tọ́ láwùjọ. Irú àwọn ìtàn àlọ́ bẹ́ẹ̀ a máa jọ ọmọdé lójú púpọ̀púpọ̀. Wọn kì í mọ̀ wí pé àròbájọ lásán ni nígbà náà.Nígbà tí àwọn

ọmọdé yóò bá fi bẹ̀rẹ̀ sí í gbọ́n; tí òye ayé óòsì máa yé wọn, kí wọ́n tó máa gbọ́n mọ̀ pé àròbájọ ni àlọ́, gbogbo òtítọ́ ilé ayé tí wọn ti fi ẹ̀kọ́ inú àlọ́ peàkíyèsí wọn sí, tí wọ́n sì ti kọ́ wọn, kò ní í kúrò ní ọkàn wọn láéláé.

Yàtọ̀ sí ìwé Pọ̀jù Àmọ̀rí (1978) tí a ti dárukọ tẹ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀, pé àwọn ìtàn àlọ́ tí ó sọ ìdí abájọ ogún ni ó wà nínú rẹ̀, o tún lè wo àpẹẹrẹ àlọ́ tó sọ ìdí abájọtí kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ fi ń jẹ adìyẹ ("Ìjàpá, Kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ àti Adìyẹ;" Babalọlá, 1973: 26 – 28), ìdí tí Àparò ṣe di aláṣọpípọ́n ('Ìjàpá sọ àparò di èrò igbó;'Babalọlá, 1973: 115-117), ìdí tí ikún fi ń gbé ilẹ̀ kiri àti ìdí tí ewúrẹ́ kò ṣe sọ̀rọ̀ mọ́, (Ọ̀pádọ̀tun, 1994: 72-74 àti 78-79).

## 4.2 Àhunpọ̀ Ìtàn

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ tẹ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀, ètò ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn ní ṣísẹ̀ntẹ̀lé láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé òpin gẹ́gẹ́ bí òǹsọ̀tàn bá ṣe gbé e kalẹ̀ ni àhunpọ̀ ìtàn jẹ́. Orísìrísìi ọgbọ́n ni àwọn apàlọ́padídùnYorùbá máa ń dá láti mú kí ìtàn àlọ́ wọn dùn kí ó sì yege nínú jíjẹ́ iṣẹ́ ìkọ́mọlẹ́kọ̀ọ́ àti ìdámọ̀làrayá tí wọ́n ń jẹ́ papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà. Àwọn àbùdá tí àwọn apàlọ́ yìí máa ń ń mú lò nínú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́Yorùbá máa ń ní ni ó jẹ wá lógún ní ìhín. Bámgbóṣe (1969) ni ó kọ́kọ́ tọ́ka sí àwọn àbùdá wọ̀nyí. Àpapọ̀ àkíyèsí mẹ́ta nípa àwọn àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ onítàn náà ni pé lákọ̀ọ́kọ́, lábalalábala ni wọ́n máa ń wà. Ìyẹn ni pé ní ọ̀pọ̀ ìgbà kì í sí ìṣùpọ̀ tí ó péye tó láàrin gbogbo àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àhunpọ̀ ìtan àlọ́. Àkíyèsí kejìni pé àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ kì í lọ́jú, ó máa ń lọ tààrà ni. Ìdí tí àhunpọ̀ ìtàn inú àlọ́ kì í fi í lọ́jú ni pé àwọn ọmọdé ni à ń pa á fún. Bí ó bá lọ́jú, ìtàn náà lè dàrú mọ́ wọn lójú. Ohun kẹta ni pé àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ kì í tún gùn jù, nípa ṣíṣe àsọtúnsọ ìṣẹ̀lẹ̀ ni ó máa ń mú kí àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ dàbí ẹni pé ó gùn díẹ̀. Àwọn, àbùdá, fọ́n-ọ́n-rán inú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ tí Bámgbóṣé (1969) fi ẹsẹ̀ wọn múlẹ̀, tí a óò sì gbé yẹ̀wò ni aṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀, ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì, ìrànlọ́wọ́ àìròtẹ́lẹ̀, àyípadà ìgbà, àti orin.

### 4.2.1 Àṣetúnṣe Ìṣẹ̀lẹ̀

Èyí ni àbùdá tàbí fọ́n-ọ́n-rán inú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ níbi tí ìṣẹ̀lẹ̀ kan náà ti ń ṣẹlẹ̀ léraléra. Ohun kan tí agbọ́dọ̀ kíyèsí nínú àbùdá yìí ni pé àyọrísí gbogbo àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ a máa jẹ́ ọ̀kan náà, àyafi èyí tí ó parí pátápátá.

Àpẹẹrẹ ni a rí nínú ìtàn àlọ́ 'Ìjàpá àti ìyá ẹlẹ́pà' (Babalọlá, 1973: 1 – 7), 'Ìjàpá àti Ìyá Alákàrà,' (Babalọlá, 1973: 20 – 25)'Ìjàpá, Àgbẹ̀ Àtàwọn Ọmọ Rẹ̀,' (Babalọlá, 1973: 50 – 54) àti 'Ìjàpá àti Bàbá Oníkàn,' (Babalọlá, 1979: 1 – 4). Nínú àwọn àlọ́ onítàn yìí Ìjàpá dá ọgbọ́n láti máa lọ jíàkàràìyá alákàrà, ẹ̀pàìyá ẹlẹ́pà,erèé bàbá àgbẹ̀àti ikànbàbá oníkàn. Ọgbọ́n tí ó máa ń dá ni pé ó máa ń sápamọ́ sí ibìkan yóò wá máa kọrinláti dẹ́rù ba àwọn ènìyàn àwọn yẹn lè sálọ, tàbí kí ó kọrin dídùn tó bẹ́ẹ̀ tí àwọn tí wọ́n bá gbọ́ ọ yóó fi ijó bẹ́ ẹ, tí wọ́n sì jó lọ, tí Ìjàpá yóòsì fi ráyè jà wọ́n lólè. Bí wọn kó ọ̀rẹ́ wá tàbí ará ìlú, ọba, ìjòyè àti àwọn

ògbójú ọdẹ pàápàá ní ọ̀wọ́ ọ̀wọ́ àti ní tẹ́léǹtẹ̀lé, bakan náà ni ọ̀rọ̀ yóò máa rí. Síwájú sí i,nínú ìtàn "Lẹ́yẹníbi àti Orogún Rẹ̀" (Ọ̀pádọ̀tun, 1994: 30 – 31),ẹ̀ẹ̀meje ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Lẹ́yẹníbi gun òkè tí ìyáálé rẹ̀ sì ń kọrin tẹ̀lé e pé kí ó wá gba abẹ̀bẹ̀ tí ó gbàgbé sílẹ̀ nígbà tí ó bínú digbá di agbọ̀n rẹ̀, tí ó kọrí sí ìlú wọn, lẹ́yìn tí ìyáálé rẹ̀ yí ti bú u ní èébú ara, tí ó sì ba èèwọ̀ rẹ̀ jẹ́. Nínú "Ìdí tí Abiamọ Kì í fi í Sin Ọmọ Délé Ọkọ,' (Ọ̀pádọ̀tun, 1994: 58 – 59), ẹ̀ẹ̀meje ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n fi gún òkè ni ọmọ tí ìyá rẹ̀ bàjẹ́ńfi orin kìlọ̀fún Ìyá rẹ̀ tí ófẹ́ bá a lọ ilé ọkọ pé kí ó padà lẹ́yìn òun. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú àpẹẹrẹ méjì tí a tọ́ka sí gbẹ̀yìn, lọ́pọ̀ ìgbà ẹ̀ẹ̀meje tàbí ẹ̀ẹ̀mẹ́ta ni iye ìgbà tí àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ máa ń sábàá wáyé nínú àlọ́ onítàn Yorùbá. Yorùbá a máa sọ pé gbọnmọgbọnmọ ni à á ránfá adití. Ohun tí èyí ń tọ́ka sí ni pé lemọ́lemọ́ ni a máa ń sọ ohun tí ó bá ṣe pàtàkì. Ìrètí Yorùbá ni pé bí a bá sọ ohun kan ní ẹ̀ẹ̀mẹta, tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ ẹni tí à ń bá sọ̀rọ̀ gbọ́dọ̀ gbọ́ ohun tí à ń bá a sọdáadáa, kò sì ní í gbàgbé bọ̀rọ̀.

Pàtàkí àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ nínú àlọ́ onítàn ni kí àwọn ọmọdé le kíyèsí ìṣẹ̀lẹ̀ náà yàtọ̀ sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ yòókù. Nínú àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ni kókó àlọ́ tàbí ẹ̀kọ́ tí àlọ́ náà fẹ́ kọ́ àwọn ọmọdé ti máa ti ń jẹ jáde jùlọ. Lẹ́yìn tí ìṣẹ̀lẹ̀ àṣetúnṣe yìí bá ti wáyé fún ìgbà mẹ́ta tàbí méje, ìgbésẹ̀ kan yóò wáyé láti fòpin sí àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ náà. Nínú mẹ́ta lara àwọn àlọ́ onítàn oloníjàpá mẹ́rin tí a kọ́kọ́ fi ṣe àpẹẹrẹ, Ọ̀sanyìn ẹlẹ́sẹ̀ kan ni wọ́n bẹ̀ lọ́wẹ̀ tí ó bá wọn mú Ìjàpá tí ó sì pa á; nípa bẹ́ẹ̀ ni àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀inú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ náà ṣe dawọ́ dúró. Nínú ìtàn àlọ́ 'Ìjàpá àti Bàbá Oníkàn' ni Bàbá àgbẹ̀ ti lọ dáfá sí ọ̀rọ̀ náà tí babaláwo sì ní kí wọn fi àkàrà rúbọ. Lẹ́yìn tí Babaláwo ti ṣe ifá sàra àkàrà náà, wọ́n fi dẹ pańpẹ́ sínú kòtò, tí wọ́n ri àwọn igi ṣóńṣó ṣóńṣoṣó mọ́ nísàlẹ̀ sí ẹ̀gbẹ́ kan nínú oko. Nígbà tí Ìjàpá tún gbé ìṣe rẹ̀ dé, tí ó kọrin bí ó ṣe máa ń kọ ọ́, tí bàbá àgbẹ̀ àti àwọn ọmọ rẹ̀ sálọ tán, Ìjàpá jáde ó jí erèé kó bí í tí í ṣe, àkàrà wá ta sánsán sí i ní imú, ló bá ní kí òun jẹ àkàrà díẹ̀, bí ó ṣe kó sínú ọdẹ tí wọ́n dẹ sínú kòtò nìyẹn. Orí ni ó mú lọ ilẹ̀, tí ó sì fi gún ṣóńṣo igi tí ó wà lábẹ́ àkàrà. Bí ó ṣe kú fin-ín fin-ín nìyẹn tí ó sì jẹ́ pé ìgbésẹ̀ yí ló fòpin sí àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn àlọ́ náà. Síwájú sí i nígbà tí orogún. Lẹ́yẹníbi bá a gún òkè keje, tí ó bá a já sí ìlú rẹ̀, ni àwọn ará ìlú náà kì í mọ́lẹ̀ wọ́n sì pa á.Bẹ́ẹ̀ náà ni nínú ìtàn àlọ́ ìyá tí ó sin ọmọ rẹ̀ lọ sílé ọkọ; lẹ́yìn tí wọ́n ti gun òkè keje tí wọ́n dé abúlé ọkọ ìyàwó, àwọn ara ilé ọkọ ti gbẹ́ kòtò gìrìwò sínú iyẹ̀wù kan, tí wọ́n sì da aṣọ bò ó. Ibẹ̀ ni wọ́n fi ìyá ìyàwó sí, tí ósì jìn sí kòtò níbi tí wọ́n ti kó póńpó àtì kùmọ̀ bò ó, tí wọ́n sì lù ú pa síbẹ̀. Pípa tí wọ́n pa àwọn obìnrin méjèèjì yìí ni ìgbésẹ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó kádìí àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ inú àhunpọ̀ ìtàn náà nílẹ̀.

### 4.2.2 Ìṣẹ̀lẹ̀ Àyísódì

Nígbà tí oríṣi àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan náà bá ṣẹlẹ̀ lẹ́ẹ̀mejì, tí àyọrísí ti ìkejì jẹ́ ìdàkejì ti àkọ́kọ́ ni a máa ń rí ìṣẹ̀ẹlẹ̀ àyísódì. Ní ọ̀nà mìíràn, nígbà tí ìṣẹ̀lẹ̀ kan bá yọrí sí búburú ṣùgbọ́n tó jẹ́ pé irúfẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ náà ti yọrí sí rere ṣíwájú, ètò àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ tí apàlọ́ mú lò nínú irú àlọ́ bẹ́ẹ̀ jẹ́ ti

aláyìísódì. Ohun tí a níláti rántí ní ìhín ni pé ẹ̀ẹ̀mejì péré ní oríṣi àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan náà máa ń wáyé nínú àhunpọ̀ ìtàn irú àlọ́ onítàn tí ó bá ní àbùdá náà. Ó lè jẹ́ ẹ̀dá ìtàn kan náà tí ó gbe àwọn ìgbésẹ̀ inú ìsẹ̀lẹ̀ àkọ́kọ́ náà ni ó tún gbé ti ẹlẹ̀ẹ̀kejì, osì lè jẹ́ ẹ̀dá ìtàn míràn ni ó gbé ti ẹlẹ́ẹ̀kejì.Ohun pàtàkì kan tí ó mú ìṣẹ̀lẹ̀ méjèèjì yàtọ̀ síra gédégédé ni pé àyọrísí ìṣẹ̀lẹ̀ àkọ́kọ́ a máa sábà dára ṣùgbọ́n ti ẹlẹ́ẹ̀kejì kìí sábà dára. Nítorí náà ni a fi máa ń rí ìṣẹ̀lẹ̀ kejì bí àyísódì ìṣẹ̀lẹ̀ kìn-ín-ní. Àwọn ìyàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ míràn tún máa ń wà tí a lè sọ pé wọ́n mú wọn yàtọ̀, ṣùgbọ́n ti ibi àyọrísí yẹn ni pabanbarì rẹ̀.

Nínuàlọ́ onítàn‘Ìjapá àti Àbọ̀n-ẹyìn’ (Babalọlá 1973: 26 – 25) nígbà tí ìyàn mú, Ìjàpá rí àbọ̀n ẹyìn (èyí tí kò tí ì pọ́n) kan kọ lẹ́yìn wàhálà púpọ̀, àbọ̀n ẹyìn yí bọ́ sínú òkun, omi sì ń gbé e lọ. Ìjàpá kań lú ibú, ó ń kọrin tẹ̀lé àbọ̀n ẹyìn náà títí ó fi dé ọ̀dọ̀ Olókun, Olókun ní òun fẹ́ lo àbọ̀n ẹyìn náà ni, ó sì fún ìjàpá ní ìgbakọ àràmàǹdà tí í máa kọ oríṣiríṣi oúnjẹ. Nígbà tí Ìjàpá délé tí ó sa òògùn ìgbakọ náà bí wọ́n ṣe ní kí ó sà á, oríṣiríṣi oúnjẹ ní ó rí, tí ó sì jẹàjẹyó àti àjẹṣẹ́kù tilétilé rẹ̀. Ìjápá bẹ̀rẹ̀ sí ṣègbéraga nítorí ìgbakọ àràmàndà rẹ̀, ó ń bọ́ gbogbo ìlú àti ọba àtìjòyè. Ní ọjọ́ kan ni wọ́n tẹ ìgbakọ rẹ̀ fọ́. NÌjápá bá tún dá ọgbọ́n ó lọkọ àbọ̀n ẹyìn míràn. Òkun kò fẹ́ ẹ́ gbé àbọ̀n ẹyìn kejì yí, ṣùgbọ́n nígbà tí ó dorí ẹlẹ́ẹ̀kẹta tí óti ńjù ú sínú ibú, omí gbé elọ. Ni ìjàpá bá tún gbá, ó fi yá a, tí ósì tún ń kọrin bí i tí ìgbà àkọ́kọ́. Nìgbà tí ó dé ọ̀dọ̀ Olókun lẹ́ẹ̀kejì, ìlagbà àràmàǹdà ni Olókun fi ta á lọ́rẹlẹ́ẹ̀kejì yí. Nígbà tí ó dénú ìyẹ̀wù rẹ̀ tí ó tún sà á bí wọ́n ṣe kọ́ ọ, ìlagbà náà nà án, gbogbo ara rẹ̀ ló lé pọ̀n-ọ̀n-nà pọ̀n-ọ̀n-nà. Lẹ́yìn tí ó jẹbò tán, ó tún ké sí gbogbo ìlú pé òún tún ti gbé ohun àràmàǹdà miràn dé. Ó kọ wọn ní ìlò rẹ̀, ó sì gba ìyọ̀ǹda láti má wà níbẹ̀. Ìyà ajẹdópin ni ìlàgbà fi jẹ gbogbo wọn tọbatọba, tìjòyètìjòyè.Nínú àlọ́ olóníjàpá yìí, a rí i pé Ìjàpá ni ẹ̀dá ìtàn tí ó gbé ìgbésẹ̀ inú ìṣẹ̀lẹ̀ àkọ́kọ́ tí óní àyọrísí tí ó dára, òun kan náà ni ó tún gbé ìgbésẹ̀ ti ìṣẹ̀lẹ̀ kejì tí ó ní àyọrísí tí kò dára. Bákan náà ni a sì rí i wí pé ìyàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ wà nínú àwọn ìgbesẹ̀ irú kan náà méjèèjì. Ní ti àkọ́kọ́, ebi ni ó sún Ìjàpá lọ kọ àbọ̀n ẹyìn, ṣùgbọ́n ìgbéraga àti ṣe-ka-rí-mi ni ó wà lẹ́yìn lílọ kọ àbọ̀n ẹyìn lẹ́ẹ̀kejì. Òkun ni ó fínnúfíndọ̀ gbé àbọ̀n ẹyìn àkọ́kọ́ nítorí Olókun nilò rẹ̀, ṣùgbọ́n Ìjàpá ni ómọ̀-ọ́n-mọ̀ ti àbọ̀n ẹyìn ẹlẹ́ẹ̀kejì sókun tipátipá, Olókun kò nílò rẹ̀. Ìgbakọ ni Olókun fún Ìjàpá ní ìgbà àkọ́kọ́, ìlagbà tàbí àtorì ní ó sì fún ni ìgbà kejì. Gbogbo èyí ni wọn jìjọ jẹ́ àtọ̀nà tàbí okùnfà àyọrísí tí ó jẹ́ àyísòdì ara wọn.

Bí a bá wo àpẹẹrẹ àwọn àlọ́ onítàn olólórógún bíí ti “Ìgbakọ Orógún mi dà àti “ Àgbìgbò Bá ń gbọ́mọ mi,” tí a ti ṣe ṣaájú, á óò rí i pé irú àbùdá àhunpọ̀ ìtàn yìí náà wà nínú wọn. Ìgbésẹ̀ tí Ìyàwó gbétí ó fi bá òde pàdé ni Ìyáálé náà lérò pé tí òún bá ti gbé, òun náà yóò ṣe oríire bọ̀ wálé, ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ pé àbámọ̀ ni ó yọrísí fún un. Gẹ́gẹ́ bí i ti ìtàn olóníjàpá tí a ti fi ṣe àpẹẹrẹ, ìyàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ máa ńwà nínú ìgbẹ́sẹ̀ àkọ́kọ́ tí Ìyàwó gbé àti ti ẹlẹ́ẹ̀kejì tí ìyáálé gbé. Bí àpẹẹrẹ nínú “Ìgbakọ Orogún Mi Dà,” ìgbakọ ṣèèṣì bọ́ sódò lọ́wọ́ Ìyàwó níbi tí ó ti lọ fọ àwọn ohun èlò ilé, ósì bá omi

lọ. Ìyáálé ló mọ̀-ọ́n-mọ̀ ti ìgbakọ tirẹ̀ sódò, àti pé ìlara, ìgbéraga àti àìnítẹ̀ẹ́lọ́rùn nínú ohun tí ìyàwó fi ta á lọ́rẹ ni ó mú kí ó kó àwọn ohun èlò ilé lọ fọ̀ lódò fúnra rẹ̀. Kò lè bá Afabẹ́rẹ́-gúnyán gúnyán bí ìyàwó ti ṣe, kò sì lè bá Bàbá elégbò yànmọ̀kàntàn fí àhọ́n lá egbò rẹ̀. Ìgbéraga àti mo-gbọ́n-tán-mo-mọ̀-ọ́n-tán ran àìnífaradà, àìnífarabalẹ̀ àti àìgbọràn lọ́wọ́ nínú ọ̀rọ̀ rẹ̀, tí kò fi ká èsó tí ó parọ́rọ́, tí wọn pa láṣe fún un pé kí ó ká. Àwọn ìdí nìyí tí ìgbésẹ̀tí Ìyáálé gbé nínú àlọ́ náà fi yọrí sí àbámọ̀ fún un; èyí tí ó jẹ́ ìdàkejì tàbí àyísódì irú igbésẹ̀ kan náà tí Ìyàwó ti kọ́kọ́ gbé. Nínú àwọn àpẹẹrẹ ti àlọ́ olólórogún wọ̀nyí, a óò kíyèsí i pé ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni àwọn ẹ̀dá ìtàn tí ó kó ipa nínú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ójọra méjèèjì.

### 4.2.3 Ìrànlọ́wọ́ Òjijì

A ti mẹ́nu bà á lókè pé àwọn ìrànlọ́wọ́ tí ẹ̀dá ìtàn àlọ́ kò rò tì tẹ́lẹ̀ a máá jẹ yọ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà nínú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ tí ó ní mòtíìfù tàbíkókó ọ̀rọ̀ amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ ìdánwò tàbí ìdíje. Àpẹẹrẹ irú ìrànlọ́wọ́ yìí wọ́pọ̀ nígbà tí a bá gbé iṣẹ́ ńlá kan tí ó ju agbára olú ẹ̀dá ìtàn àlọ́ lọ fún unláti ṣe, tàbí tí ó ń kópa nínú ìdíje kan, tí wọ́n sì ń ṣe inúnibíni rẹ̀. Nígbà mìíràn,irú olú ẹ̀dá ìtàn àlọ́ bẹ́ẹ̀ a máa rí ìrànlọ́wọ́gbà nígbà tí ẹ̀dá ìtàn òṣebí bá dẹ pàkúté burúkú tàbí tí ó gbẹ́ ọ̀fin kan sílẹ̀ fún un láti kó sí. Nígbà míràn ẹ̀wẹ̀, irú olú ẹ̀dá ìtànbẹ́ẹ̀ kàn lè bá ara rẹ̀ ní ipò ìṣoro kań tàbí òmíràn, tí kì í ṣe pé ẹnìkan ni ó fi ṣe dẹ pańpẹ fún un. Kókó ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí tí irú ìrànlọ́wọ́ bẹ́ẹ̀ máa ń fi múlẹ̀ ni pé "Ọmọ olóore kan kì í kú sí ipò ìkà" àti pé "Kàkà kí ọmọ olóore ó jìn sí kòtò láàjìn, mọ̀nàmọ́ná ákọ yẹ̀rì." Nígbà tí a bá gbé iṣẹ́ kan tó le fún olú ẹ̀dá ìtàn àlọ́, tàbí a gbẹ́ ọ̀fìn kan dè é, ìkóniláyàsókè a máa wà fún àwọn ọmọdé tó ń gbọ́ àlọ́. A máa dàbí ẹni pé ẹ̀dá ìtàn tí a fún níṣẹ́ ṣe tàbí tí a gbẹ́ ọ̀fìn dè yóò bá iṣẹ́ tí a gbé fún un tàbí ọ̀fìn tí a gbẹ́ dè é lọ. A wá rí bí ẹni pé akùdé fẹ́ dé bá àhunpọ̀ ìtàn àlọ́. Láti ipasẹ̀ ìrànlọ́wọ́ àìròtẹ́lẹ̀ tí ẹ̀dá ìtàn náà bá rí gbà, ìkóláyàsókè tó ti ṣẹlẹ̀ sí àwọn olùgbọ́ yóò wálẹ̀. Torí pé àyà wọn tí ó kó sókè wálẹ̀ nípasẹ̀ ìránlọ́wọ́ náà, a lè rí àwọn ìrànlọ́wọ́ inú àlọ́ onítàn náà Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ìṣẹ̀lẹ̀ atunilára àti ọgbọ́n láti mú kí àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ tẹ̀ síwájú.

Àpẹẹrẹ irú ìrànlọ́wọ́ bẹ́ẹ̀ jẹ yọ nínú ìtàn àlọ́ 'Àwọn Àdó Mẹ́ta tí Ó ń Sọ̀rọ̀' (Apata, a kò mọ ọdún ìgbéjádé: 19). Nínú ìtàn àlọ́ yìí, Ìyawó lo omi òjò tí ìyálé gbè, ìyálé sì ní àfi bó wá omi òjò lọ sí ọ̀run fún òun, torí pé òjò kò rọ̀ mọ́ ní àkókò tí ìṣẹ̀lẹ̀ náà ṣẹlẹ̀. Gbogbo àwọn tí ó pàdé lọ́nà ọ̀run ló ràn án lọ́wọ́ torí pé òun náà hùwà ọmọlúwàbí. Nígbà tó dé ọ̀run, ó rí ìyá arúgbó kan tó ràn án lọ́wọ́,tó fún un ní omi òjò ọ̀run, tó sì tún fún un ní àdó mẹ́tà tó sọ ọ́ di ọlọ́rọ̀ rẹpẹtẹ nígbà tó dé ilé ayé. Nínú ìtàn àlọ́ 'Àdíjátù kẹkẹlúkẹ,' tí a ti tọ́ka sí ṣaájú, irú ìrànlọ́wọ́ yìí ni orin tí Ìyá Àdíjátù tí ó ti kú , tí ó di ẹyẹ, tí ó wá ń kọrin láti ṣọ fún Àdíjátù pé Ọba ni ó gbékun lémú, tí ó sì wọ ẹ̀wù àkísà.Bákan náà ni Ìjàpá rí ìrànlọ́wọ́ gbà lọ́wọ́ Olókun nígbà tí àbọ̀n ẹyìn rẹ̀ já sómi. Olókun fún un ní ìgbakọ àràmàǹdà tó ń se ọ̀pọ̀lọpọ̀ oúnjẹ fún un (Babalọlá, 1973). Ó yẹ kí á kíyèsí i pé, kì í ṣe ẹ̀dá ìtàn òṣebi kankan ni ó gbé ìdánwò ka iwájú Ìjàpá

nínú àhunpọ̀ ìtànàlọ́ náà, ebi tí ó ńpa Ìjàpá àti ìdílé rẹ̀, nítorí ìyàn tí ó mú ní ìlú wọn ni ó mú kí ó lọ kọ àbọ̀n ẹyìn lórí ọ̀pẹ. Ó bá ara rẹ̀ nínú ìṣoro náà ni.

## 4.2.4 Àyípadà Ìgbà

Àyípadà ìgbà a máa bá àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ láti ipò búburú bọ́ sí ipò dáradára tàbí láti ipò dáradára bọ́ sí búburú. Bí ẹ̀dá ìtàn àlọ́ tó ń hùwà rere bá wà ní ipò tí ó burú tàbí tí ó kù káàtólọ́nà kan tàbí òmíràn níbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn, ìwà rere rẹ̀ a máa ṣílẹ̀kùn ìpò dáradára fún un nígbẹ̀yìn. Bí ẹ̀dá ìtàn àlọ́ tó ń hu ìwà búburú bá wà ní ipò ọlá tàbí ipò dáradára mìíràn níbẹ̀rẹ̀, ìwà búburú tó ń hù yóò ṣílẹ̀kùn ìpò àìní tàbí ipò búburú fún un nígbẹ̀yìn. Ìyípadà láti ipò búburú bọ́ sí ipò dáradára tàbí láti ipò dáradára bọ́ sí ipò búburú ní à ń pè ní àyípadà ìgbà. Àyípadà ìgbà máa ń jẹ́ kí àlọ́ onítàn ní ìgbà méjì; àkọ́kọ ni ìgbà ìpọ́njú, èkèjì ni ìgbà ayọ̀. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà nínú àlọ́ onítàn, ìgbà ìpọ́njú ni ó máa ń ṣíwájú fún ẹ̀dá ìtàn rere nígbà tí ìgbà ìpọ́njú rẹ̀ yóò yí padà di ayọ̀. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú ojú ìwòye tó sọ pé, “Bí ẹ̀kún bá gba alẹ́ kan, ayọ̀ ń bọ̀ ní òwúrọ̀.” Ní ọ̀nà kejì, ìgbà ayọ̀ tàbí ìgbà rere ni ó máa ń ṣíwájú fún ẹ̀dá ìtàn àlọ́ òṣebi lọ́pọ̀ ìgbà ṣùgbọ́n tí ìgbà yìí yóò yí padà di ìgbà ìkorò ní ìgbẹ̀yìn. Èyí náà wà ní ìbámu pẹ̀lú òwe Yorùbá tó sọ pé “Bí àlọ bá lọ, àbọ̀ ń bọ̀.”

Nínú àlọ́ ‘Àwọn Àdó Mẹ́ta tí Ó ń Sọ̀rọ̀,’ àyípadà dé bá Ìyàwó onísùúrù láti ipò àìní sí ìpò ọlọ́rọ̀ lẹ́yìn tí ó ti ọ̀run dé. Bákan náànínú ìtàn ‘Pankoko’ àyípadà ìgbà dé bá Pankoko, tí ó jẹ́ arọ, tí ìyá rẹ̀ fi ọgbọ́n yọ́ sílẹ̀, tí ó sì kó àwọn ọmọ rẹ̀ mẹ́fà yókù tí wọ́n rẹwà sálọ, torí pé ọmọ náà burẹ́wà. Nígbẹ̀yìngbẹ̀yìn, Pankoko ni ó wá padà di ọba ìlú tí ìyá rẹ̀ sá lọ,tí àwọn ọmọ arẹwà mẹ́fẹ̀ẹ̀fà tí ó gbójú lé sì wọ́ kú. Àyípadà sí rere ni ó dé bá Ìyàwó onísùúrù àti Pankoko nínú àwọn ìtàn náà. Àpẹẹrẹ àyípadà ìgbà sí búburú ṣẹlẹ̀ nínú ìtàn ‘Ọba Olómù’ sí ọba tó jí òkété, tí ó sì tipa bẹ́ẹ̀, rẹ́ ọmọkùnrin tálákà kan jẹ́. Ọwọ́ pálábá ọbà yìí ségi, àwọn ìlú sì dájọ́ ikú fún un. Èni àyẹ́sí rẹ̀ wá dẹni yẹpẹrẹ,tí ó kú ikú ìtìjú. (Àpáta, nd.: 25-27). Bákan náà ni àyípadà búburú ló ṣelẹ̀ sí Ìlósùn nínú àlọ́ ‘Ìlẹ́rẹ́ àti Orogún rẹ̀’ (Ọ̀pádọ̀tun, 1994: 86-87). Ìlósùn parọ́ mọ́ orogún rẹ̀ pé ó fọ́ ọpọ́n. Èyí ló sì ṣekú pa á. Lẹ́yìn ìgbà díẹ̀, àṣírí tú, wọ́n sì pa Ìlósùn nàà.

## 4.2.5 Orin

A ti ṣe àgbéyẹ̀wò orin àlọ́ ní abẹ́ ewì ọmọdé. A sì tún ti tọ́ka sí oríṣiríṣi àpẹẹrẹ orin àlọ́ nínú àwọn àlàyé wa. Nítorí náà ohun tí a óò gbájú mọ́ ní ibí ni ipa tí orin ń kó nínú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́. Àwọn ọmọdé tí wọ́n jẹ́ olùgbọ́ àlọ́ a máa fójú sọ́nà fún àkókò tí wọn yóò kọ orin nígbà tí apàlọ̀ọ́ bá ń pa àlọ́ fún wọn nítorí ní àkókò náà ni wọn máa ń ní àǹfàní láti túraká, tí wọ́n yóò gbe orin, tí wọ́n yóò patẹ́, tí wọ́n yóò lùlù, tí wọ́n yóò sì jó. Lára ohun tí ó máa ń mú wọn gbádùn àlọ́ pípa nìwọ̀nyẹn. Ṣùgbọ́n iṣẹ́ gan-an tí a ń fi orin jẹ́ nínú àhunpọ̀-ìtàn àlọ́ ni síso àwọn abala abala

àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ pọ̀. Wọ́n máa ń dúró bí okùn tí a fi só ìṣẹ̀lẹ̀ ìṣaájú pọ̀ mọ́ èyí tí ó tẹ̀lé e. Níbi àwọn àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì ni irú àwọn orin bẹ́ẹ̀ ti máa ń wáyé jù lọ nínú àhunpọ̀ ìtàn. Orin wà lára àwọn ohun tí ń mú kí àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ gùn, nítorí ọ̀gangan íbi àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ tí a sọ pé óti máa ń wáyé. Nínú ìṣẹ̀lẹ̀ kọ̀ọ̀kan tí a ń tún ṣe tún ṣe ni orin yóò ti máa wáyé.

Orin lè jẹ́ ìsọníṣókí ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ti ṣẹlẹ̀ sẹ́yìn, ìtẹnumọ́ ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́tàbí àpapọ̀ méjèèjì nígbà míràn. Bí àpẹẹrẹ, bí orin inú àlọ́ 'Ọba Aláràn-án àti Ẹyẹ Kìnkin'(Àpáta a kò mọ ọdún ìgbéjáde: 1 – 3) tiránni létí ìṣẹ̀lẹ̀ àtẹ̀yìnwá ni ó tẹnu mọ́èyí tó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́. Bákan náà ni ó rínínú ìtàn àlọ́ 'Ìjàpá lóyún ìjàngbọ̀n' (Babalọlá, 1973: 78 – 82) àti 'Ìjàpá lọ jẹun lọ́dọ̀ Ìyá ajá,'(Babalọlá, 1973: 65 – 75),ṣùgbọ́n ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ nìkan ni orin inú ìtàn àlọ́ 'Ìjàpá àti Ìyá ẹlẹ́pà'(Babalọlá, 1973: 1 – 7) àti 'Ìjàpá àti ajá lọ jí iṣu wà'(Babalọlá, 1973: 39 – 44) ń dúnnu mọ́.Gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nu bà á ṣaájú orin inú àlọ́ wà lára ohun tí ó mú àwọn ọmọdé gbádùn àlọ́. Ju gbogbo rẹ̀ lọ iṣẹ́ kan tí àwọn orin àlọ́ tún máa ń jẹ́ ni pé wọ́n máa ń jẹ́kí àwọn ọmọ tètè rántí àhunpọ̀ ìtàn àlọ́. Bí wọ́n bá ti rántí orin, wọn óò rántí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ pàtàkìpàtàkì tí orin náà mẹ́nu bà, èyí yóò sìjẹ́ àtọ́nà fún rírántí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ yòókù inú àhunpọ̀ ìtàn náà.Lọ́rọ̀ kan a lè sọ pé orin dúro bí i kánàkò amọ́mọrántí àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ onitàn.

## 4.3 Àkókò àti Ibùdó Ìtàn

Bí a bá fi ojú ìgbà tí àwọ́n ìṣẹ̀lẹ̀ ṣẹlẹ̀ nínú àhunpọ̀ ìtàn wo àlọ́, kò sí ìgbà tí a ní lójú ayé tí ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́ onítàn kò le ṣẹlẹ̀. Ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́ le ṣẹ̀lẹ̀ ní kò-ríni-kò-mọni,kùtùkùtu òwúrọ̀, ìyálẹ̀ta, ọ̀sán gangan,ọjọ́rọ̀, alẹ́, tàbí ààjìn.Ibùdó ìtàn inú àlọ́ lè jọ ojú ayé, ó lè jẹ́ àjùlé ọ̀run, ó lè jẹ́ inú ibú, ó sì lè jẹ́ inú òkè, abẹ́ òkúta àti àwọn ààyè kàyéfì tàbí mérìíyìírí mìíràn. Ó ṣé é ṣe kí ẹ̀dá ìtàn mérìíyìírí kópa ní ibùdó ìtàn tí kì í ṣe mérìíyìírí. Bákan náà ni ẹ̀dá ìtàn tí kì í ṣe mérìíyìírí náà lè kópa ní ìbùdó ìtàn mérìíyìírí. Kò sí àní àní pé ayé àràmàǹdà, ayé mérìíyìírí ni ayé inú àlọ́ onítàn. Bí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́ ṣe máa ń ṣẹlẹ̀ máa ń yàtọ̀ sí ti ojú ayé. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, nínú àlọ́, ìwin, òkú, ọ̀rọ̀ le rìn ní ọ̀sán gangan, wọ́n le rìn ní ààrọ̀ tàbí alẹ́. Ní ojú ayé, gẹ́gẹ́ bí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá, bí ọ̀sán kò bá pọ́n ganríganrín tàbí ní ààjìn jìndùn, àwọn ẹ̀dá abàmì yìí kì í rìn. Àwọn ẹ̀dá ìtàn abàmì yìí a máa ní àjọṣepọ̀ ojúkojú nínú àlọ́ pẹ̀lú àwọn èniyàn ní ìgbà ìyówù nínú ọ̀jọ́ àti ní ibikíbi tàbí ààyèkááyè, èyí kì í rí bẹ́ẹ̀ ní ojú ayé. Àwọn tí wọ́n bá wẹjú nìkan si ni wọ́n lè rí wọn ní ojúkojú ní ojú ayé lọ́pọ̀ ìgbà.Ní ojú ayé, a kì í réwú ní ọ̀sán ṣùgbọ́n ní inú àlọ́, kò sí ìgbà tí ewú kò le jádé. Bí ó ṣe ń dífá ọ̀sán ló ń dá tòru. Bákan nááni ójẹ́ pé ní ojúran àti ní ojú àlá ni a ti máa ń sábàá bá àwọn abàmì ẹ̀dá bí i òkú tàbí àǹjànnú pàdé, kì í sabàá jẹ́ ojúkorojú bí i ti inú àlọ́.

Lóòtọ́ ni pé apàlọ́ fẹ́ kí àwọn ọmọ tí wọ́n jẹ́ olùgbọ̀ọ́ àlọ́ nígbàgbọ́ pé ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́ sẹlẹ̀ rí láyé àtijọ́tijọ́, idí nìyí tí wọ́n fi máa ń bẹ̀rẹ̀ àlọ́ wọn

pẹ̀lú "Ní ìgbà kan,"tí àwọn ọmọ náà sì lè dáhùn pé "Ìgbà kan ń lọ, ìgbà kan ń bọ̀, ìgbà kan kò lo ilé ayé gbó," síbẹ̀ a mọ̀ pé àròbájọ ni àlọ́; kì í ṣe pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà ṣẹlẹ̀ lóòtọ́. Ìyẹn ni pé àti àkókò inú àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ àti ibùdó rẹ̀, pẹ̀lú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí wọn ṣẹlẹ̀ níbẹ̀ pọ̀ mọ́ àwọn ẹ̀dá ìtàn tí ó tukọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà pàápàá, ni kì í ṣe òótọ́. ìdí tí àwọn Yorùbá fi ń sọ pé "Irọ́ ní ń jẹ́ àlọ́" nìyẹn, tí àwọn ọmọ, tí wọ́n jẹ́ olùgbọ̀ọ́ àlọ́ sì fi níláti fẹnu kò pẹ̀lú àpàlọ́ pé gbogbo ohun tí apàlọ́ bá hun (tàbí tí ó fi ọgbọ́n ìpàlọ́padídùn gbé) kalẹ̀ ni àwọn ó gbàgbọ́ láti ibi ìṣíde àlọ́ pípa, nígbà tí apàlọ́ sọ pé "Ààlọ́ o!" tí àwọn ọmọ náà sì dáhùn pé "Ààlọ̀!" gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ti ṣe tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀.

Lára àwọn ohun tí ófi hàn gbangba wí pé àkókò àti ibùdó ìtàn inú àlọ́ onítàn kàn lè jọ ti ojú ayé ni, wọn kì í ṣe ti ojú ayé rárá ni pé wọ́n máa ń jẹmọ́ mérìíyìírí. Nínú àlọ́ onítàn ènìyàn lè rìnrìn àjò lọ sí òde ọ̀run tàbí ilé ikú, kí ó sì tún padà. A lè rí àpẹẹrẹ irú èyí nínú àlọ́ olólórogún'Àwọn àdó mẹ́ta tí ó ń sọ̀rọ̀'(Àpáta a kò mọ ọdún ìgbéjáde, 6 – 9) tí a ti mẹ́nu bà a rí i pé ọ̀run ni Ìyàwó tí ó lo omi òjò Ìyáálé rẹ̀ wá omi náà lọ nígbà tí ìyáálé fi dandan lé e pé kí ó dá omi òjò náà padà, tí òjò kò sì rọ̀ mọ́.Kò pẹ́ tó bẹ́ẹ̀ jù bẹ́ẹ̀ lọ tí ó fi padà dé. Bẹ́ẹ̀ náà ni ó jẹ́ pé inú òṣùpá, lójú ọ̀run ni Ajá lọ gbé ìyá rẹ̀ pamọ sí nínú àlọ́ 'Ìjàpá lọ jẹun lọ́dọ̀ Ìyá Ajá'(Babalọla 1973: 65 – 75), tí ó sì máa ń lọ ọ̀dọ̀ rẹ̀ lálọbọ̀ lẹ́ẹ̀mẹta lójúmọ́, láti jẹunnígbà tí gbogbo àwọn ẹranko yòókù ti pa ìyá wọn jẹ nítorí ìyàn tí ó mú. Bákan náà ni a rí i pé nínú ìtàn 'Ọlọ́rànmọdùn', ìdánwò tí olówó rẹ̀, tí ó kórìíra rẹ̀, gbé fún un gbẹ̀yìn ni kí ó lọ mú Ikú wá fún òun. Ọmọ náà sì lọ sí ile Ikú ní àlọbọ̀, ó gbé Ikú wá fún ọ̀gá ìkà náà. Ikú náà ni ó sì pa ọ̀gá burúkú yìí. Ohun kan tí afẹ̀ pe àkíyèsí sí ni wí pé ní ojú ayé, bí a ṣe mọ̀ ọ́n, àrèmabọ̀ ni ọ̀run; kò sẹ́ni tí ó lọ tí ó bọ̀ rí, àyàfi lójú àlá. Bákan náà sì ni ọ̀rọ̀ ikú; ó di gbéré, ó dí àrìnnàkò àyàfi ojú àlá fún ẹni bá fojú bakú. Lára iṣẹ́ líle tí ọ̀gá náà tí kọ́kọ́ gbé fún Ọlọ́rànmọdùn ni wí pé kí ó gbin ẹ̀fọ́ ọ̀sùn sí orí apáta, kí ó hù ní òòjọ́ nítorí òun fẹ́ fi jẹ ẹ̀kọ lálẹ́ ọjọ́ náà. Ní ojú ayé, èyí kò lè ṣe é ṣe, nítorí ẹ̀fọ́ náà kò le hù ní orí àpáta tí ó ní kí ọmọ náà gbìn ín sí, bí yóò bá tilẹ̀ wá hù nítorí ìdí kan tàbí ìkejì, kò lè jẹ́ òòjọ́ ni yóò sọ, ni yóò hù jáde, tí yóò dàgbà, tí wọn yóò fẹ́ ẹ, tí wọn yóò sì sè é jẹ. Ṣùgbọ́n nípa ìrànlọ́wọ́ bàbá rẹ̀, ọmọ yìí ṣe àṣeyọrí nínú ìdánwò náà.

Ohun tí a kò gbọdọ̀ gbàgbé ni pé "irọ́" tí Yorùbá sọ pé àlọ́ jẹ́, kì í ṣe irọ́ tí a fi ń ṣèké rárá. Àròsọ ti à tinú ṣẹ̀dá láti gbé òtítọ́ kalẹ̀ ni – "irọ́ bí òótọ́" ni. Ohun tí a kò gbọ́dọ̀ gbàgbé ni pé ẹ̀kọ́ tí ó wà nínú ìtàn àlọ́ ni òtítọ́ ilé ayé tí àwọn apàlọ́ Yorùbá fẹ́ kí àwọn ọmọ ó mọ̀, kí wọ́n sì dì mú. Èyí ni ó ṣe pàtàkì ju ọ̀rọ̀ ibúdó ìtàn àti àkókò ìtàn lọ. Ọgbọ́n ìṣàgbékalẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn tí yóò fi jọ àwọn ọmọdé lójú, tí yóò sì fa wọ́n mọ́ra ni ìmúlò àgbékalẹ̀ irúfẹ́ àkókò àti ìbùdó ìtàn inú àlọ́ onítàn jẹ́. A lè fi ewé tí a fi pọ́n ọ̀lẹ̀lẹ̀ rodò ṣe àkàwé àgbékalẹ̀ àkókò àti ìbùdó ìtàn nínú àlọ́ onítàn. Ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúwàbí inú ìtàn àlọ́ ni ọ̀lẹ̀lẹ̀ gan-an yóò wá já sí nínú àkàwé náà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ewé kò ṣe pàtàkì tó ọ̀lẹ̀lẹ̀, tí ó jẹ́ pé tí a bá

ti jẹ ọ̀lẹ̀lẹ̀ tán, jíjù ni a óò jù ewé nù; síbẹ̀, ewé ni a fi ṣu ọ̀lẹ̀lẹ̀pọ̀ láti ilẹ̀ wá tí a sì fi sè é jinná. Bẹ́ẹ̀ náà ni ìgbékalẹ̀ ibùdó ìtàn àti àkókò rí nínú àlọ́ onítàn pípa sí àwọn kókó ọ̀rọ̀ inú rẹ̀. Ohun tí à ń pe àkíyèsí sí ni pé ibùdó àti àkókò ìtàn náà ṣe pàtàkì ní ààyè ti wọn, bí ṣíṣe pàtàkì wọn kò tilẹ̀ tó ti ẹ̀kọ́ àti òye ọ̀rọ̀ ibẹ̀. A kò gbọdọ̀ fojú tẹ́ńbẹ́lú iṣẹ́ "ọ̀gẹ̀dẹ̀ tí ó wo kòkó yè...," gẹ́gẹ́ bí òwe Yorùbá kan ti fi yé wa. Kì í ṣe ọ̀rọ̀ ibùdó ìtàn tàbí àkókò gan-an ni ó ṣe pàtàkì nínú àlọ́ onítàn pípa; ohun tí ó ṣe pàtàkìjù lọ ni ẹ̀kọ́ ìwà tí a fẹ́ kí àwọn ọmọdé kọ́.Ara ọgbọ́n ìsọ̀tàn ìpàlọ́-pa-dídùn láti mú ọkàn àwọn ọmọdé mọ́lẹ̀, kí wọ́n lè ní ìfẹ́ láti máa gbọ́ ìtàn àlọ́ ni ṣíṣe àmúlò àwọn ibùdó ìtàn ati àkókókò mérìíyìírí gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ti ṣe tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Àwọn ohun tí a ṣàlàyélé lórí nínú ìdánilẹ̀kọ̀ọ́ yìí ni kókó ọ̀rọ̀, àhunpọ̀ ìtàn, ibùdó àti àkókò inú àlọ́ onítàn Yorùbá. Kókó ọ̀rọ̀ inú àlọ́ ni a pín sí méjì: àkọ́kọ́ ni olú kókó ọ̀rọ̀ tí ó jẹ́ ìwà ọmọlúàbí. Ọ̀nà tí a máa ń gbà ṣe ìgbékalẹ̀ ìwà ọmọlúàbí, tí a jíròrò lé lórí, nínú ìdánílẹ́kọ̀ọ́ yìí ni bíbu ẹnu àtẹ́ lú àwọn tí wọ́n hu ìwà àìdára àti yíyòǹbó tàbí gbígbé oríyìn fúnàwọn tí wọ́n hu ìwà dídára/ rere. Kókó ọ̀rọ̀ kejì ni àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀. Bí a bá wò ó dáradára, a óó rí i pé oríṣi méjì ni àwọn yìí náà. Àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ tààrà ni àwọn ìwà dídára àti àìdára tí a fi ń kọ́ni níwà ọmọlúwàbí. Àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ lọ́nà ẹ̀rọ ni àwọn mìíràn tí wọn kò jẹ mọ́ ẹ̀kọ́ ìwà tààrà bí kò ṣe ní ọ̀nà ẹ̀rọ. Àwọn ni a sọ pé a tún ń pè ní mòtíìfù.Wọn a máa ṣe ìrànwọ́ láti wa ọ̀rọ̀ ìwà ọmọlúwàbí gúnlẹ̀ dáradára. Àwọn náà ni ẹ̀san, ìdí abájọ, ìdánwò/ ìdíjeàti ìjà orogún.Àkíyèsí gbogbogbòò mẹ́ta tí a ṣe nípa àhunpọ̀ ìtàn ni pé láblalábala ni wọ́n máa ń wà, wọn kì í lọ́jú, wọ́n máa ń lọ tààrà ni bẹ́ẹ̀ nni wọn kì í sì í gùn. Àwọn àbùdá tàbí fọ́nrán àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ onítàn Yorùbá tí a sì jíròrò lé lórí ni àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀, ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì, ìrànlọ́wọ́ àìròtẹ́lẹ̀, àyípadà ìgbà àti orin. A ṣàgbéyẹ̀wò àkókò ìtàn àti ibùdó ìtàn náà. A sọ nípa bí ó ṣe jẹ́ pé mérìíyìírí ni wọ́n, tí ó sì jẹ́ pé lárá ọgbọ́n ìpàlọ́padídùn tí a máa ń fi ṣàgbékalẹ̀ àlọ́ onítàn ni wọ́n.

Kò sí àní àní kankan wí pé fún kíkọ́ àwọn ogo wẹẹrẹ ni ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúwàbí láti pínìṣín wọn ni àlọ́ onítàn wà fún. Àwọn Yorùbá a sì tún máa lò ó láti pe àkíyèsí àwọn ọmọdé sí àyíká wọn bákan náà, bí a ti fi hàn nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìlànà ọgbọ́n ìsọ̀tàn ìpàlọ́padídùn tí wọ́n máa ń mú lò láti jẹ́ àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí jẹ́ ti mérìíyìírí. Lílo irú ọgbọ́n ìkọmọ lẹ́kọ̀ọ́ láti pínnìṣín báyìí nìígbà tí ọwọ́ bá dilẹ̀ jẹ́ èyí tí ó wọ́pọ̀ ní àárín àwọn aláwọ̀ dúdú ilẹ̀ Áfíríkà àti káàkiri ní àgbáyé.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ṣe àlàyé àwọn ọ̀nà méjì pàtàkì tí a le pín kókó ọ̀rọ̀ inú àlọ́ onítàn sí. Fi àpẹẹrẹ méjì     méjì gbe àlàyé rẹ lẹ́sẹ̀?

2.. Jíròrò lórí ìgbékalẹ̀ àkókò àti ibùdó ìtàn nínú àlọ́ onítàn Yorùbá.
3. Ṣe àgbéyẹ̀wò ọ̀nà méjì tí a fi máa ń ṣe ìgbékalẹ̀ ìwà ọmọlúwàbí gẹ́gẹ́ bí olú kókó ọ̀rọ̀ àlọ́ onítàn Yorùbá.
4. Kin ni ìyàtọ̀ láàrín àwọn àbùdá àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ méjì wọ̀nyí: àṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ àti àyísódì ìṣẹ̀lẹ̀? Lo àpẹẹrẹ méjì méjì fún ìkọ̀ọ̀kan láti ṣe àlàyé ìdáhùn rẹ ní kíkún.
5. Jíròrò lórí ipò orin ninú àhunpọ̀ àlọ́.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Awóníyì, A. 1981.*Ìtàn F'ọ́mọdé L'áyé'jọ́un*, Thomas Nelson (Nigeria) Ltd., Lagos.

Àmọ̀ó, A. 1987.*Àlọ́ Àpagbè*. Evans (Nigeria) Publishers Ltd.,Ìbàdàn.

Àmọ̀rí, Pọ̀jù 1978. Ìdí Abájọ *Kìnnìún àti àwọn ẹranko mìíràn*. Macmillan Nigeria Publishers Ltd.,Lagos.

Àpata, F.O. A kò mọ òdún ìgbéjáde.*Àwọn Ìtàn Aládùn*. Ministry of Education,Ìbàdàn.

Babalọlá, A. 1973. *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá: Apá Kìíní*. University Press Limited,Ìbàdàn.

Babalọlá, A. 1979. *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá: Apá Kejì* University Press Limited,Ìbàdàn.

Bámgbóṣe, A. 1969 Yorùbá Folktales, *Ìbàdàn*, 6 -12; Àtúntẹ̀ jjáde nínú Lawal, N. S., Sadiku, N. O. S àti Dọ̀pámú A. 2000*Understanding Yorùbá Life and Culture*; New Jersy: 547 – 561.

Fuja, A. 1967.*Four Hundred Cowries: Traditional Stories of the Yorùbá*, Oxford University Press, Ìbàdàn.

Ògúndèjì, P.A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. University of Ìbàdàn Centre for External Studies,Ìbàdàn.

Òjó, O. *Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yánníbo*, Longman Nig Ltd.,Lagos

Ọnàsànyà, O. 1973.*Àṣàyàn ìtàn Ọmọ Obòkun*, Macmillan NigeriaPublishers Ltd.,Lagos.

Ọ̀pádọ̀tun, Ọ. 1994. *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Y-Books.,Ìbàdàn.

# ÌPÍN 3 ÀLỌ́ ONÍTÀN II: ẸDÁ ÌTÀN, ÌFÌWÀWẸ̀DÁ ÀTI ÌLÒ ÈDÈ

## AKÓÓNÚ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròńgbà àti Ìfìwàwẹ̀dá
3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ẹ̀dá Ìtàn
4.1.1 Ẹlẹ́mìí tí ńmí
4.1.1.1 Ajẹménìyàn
4.1.1.2 Ajẹmẹ́bọra
4.1.1.3 Ajẹmẹ́ranko
4.1.2 Aláìlẹ́mìí
4.1.2.1 Ajẹméwéko
4.1.2.2 Ajẹmókùúta àti Àwọn Ohun Àfojúrí/Àrídìmú Mìíràn
4.1.2.3 Àìfojúrí/Àfòyemọ̀
4.2 Ìfìwàwẹ̀dá
4.2.1 Orúkọ
4.2.1.1 Orúkọ Alárokò
4.2.1.2 Orúkọ Ipò Láwùjọ
4.2.1.3 Orúkọ Ìrísí
4.2.1.4 Orúkọ Ìsọmọ
4.2.1.5Orúkọ Àwọn Ẹ̀dá Ìtàn tí kì í Ṣènìyàn
4.2.2 Àpèjúwe àti Ìsínjẹ
4.3 Ìlò Èdè
4.3.1 Àbùdà Àwọn Gbólóhùn Àárín Àhunpọ̀ Ìtàn
4.3.2 Bátànì Gbólóhùn Ìparí Ìtàn
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ẹ̀dá ìtàn ni àwọn akópa tí òníṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ dá aṣọ ìwà ènìyàn wọ̀, tí wọn ń kó ipa kan tàbí òmíràn nínú ìṣẹ̀lẹ̀ inú àhunpọ̀ ìtàn. Nínú àlọ́ onítàn, kò sí ohun kan tó wà nínú ayé tí kò le kópa gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn, pàtàkì jùlọ bí apàlọ́ bá ti lè ṣe àgbékalẹ̀ ìrísí, ìṣesí tàbí ìhùwàsí ohun náà. Nínú àlọ́ onítàn, ẹ̀dá ìtàn le jẹ́ ènìyàn, ó sì lè jẹ́ ohun tí kì í ṣe ènìyàn. Àwọn ohun tí kì í ṣe ènìyàn lè jẹ́ ẹlẹ́mìí tàbí aláìlẹ́mìí bí igi, ewéko àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Gbogbo àwọn yìí ni apàlọ́ máa ń dáṣọ ìwà kan tàbí òmíràn wọ̀. Dídáṣọ ìwà wọ ẹ̀dá ìtàn nínú àlọ́ onítàn láti ṣe ojúṣe kan tàbí òmíràn ni a mọ̀ sí ìfìwàwẹ̀dá (ì-fi-ìwà-wọ-ẹ̀dá). Lára ọ̀nà tí a le fi dáṣọ ìwà wọ ẹ̀dá ìtàn ni

orúkọ tí a fún ẹ̀dá ìtàn náà àti àgbékalẹ̀ìrísí, ìhùwàsí àti ìṣesí rẹ̀. Nígbà tí a bá ń fi ìwà wọ ẹ̀dá, tí ìtàn àlọ́ ń tẹ̀ síwájú, èdè tí apàlọ́ fi ń gbé ìfìwàwẹ̀dá kalẹ̀, àti èyí tó fi sín àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ kan jẹ, àti èyí tí àwọn agbálọ̀ọ́ fi dá sí àhunpọ̀ ìtàn àlọ́, àti èyí tí òun àti àwọn agbálọ̀ọ́ fi ṣe àgbékalẹ̀ ìsọ̀rọ̀ngbèsì lásìkò tí à ń pàlọ́ lọ́wọ́ ni a kà sí àmúlò èdè nínú ìtàn àlọ́ Yorùbá.

## 2.0 Èròngbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó ti lè ṣàlàyé bí a ṣe ń ṣe àgbékalẹ̀ ẹ̀dá ìtàn nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá. O ó lè sọ, o ó sì lè ṣeàpẹẹrẹorísìrísì irú àwọn ẹ̀dá ìtàn tí a máa ń bá pàdé nínú àlọ́ onítàn pẹ̀lú. O ó lè ṣàlàyé bí orúkọ wọn, ìrísí, ìṣesí àti ìhùwàsí wọn ṣe ń kópa pàtàkì nínú bí a ṣe ń fi ìwà wọ̀ wọ́n. O ó tún lè ṣàlàyé àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn inúàwọn  àlọ́ onítàn Yorùbá.Yàtọ̀ sí àwọn èyí o ó tún le ṣe àlàyé nípa àmúlò èdè nínú àlọ́ onítàn pẹ̀lú àpẹẹrẹ tí ó péye.

3.0 Ìbéèrè Ìṣaájù

1. "Mérìíyìírí ni gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́." Kín ni èrò rẹ nípa àlàmọ́lẹ̀ yí?
2. Ṣe àlàyé ohun tí o mọ̀ nípa ìṣàmúlò orúkọ aláròkò fún ìfìwàwẹ̀dá nínú àlọ́ onítàn.
3. Ṣe àdàkọ  àpẹẹrẹ ìpèdè ìṣíde àlọ́ méjì àti ti ìkádìí àlọ́ méjì tí o mọ̀.

# 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 Ẹ̀dá Ìtàn

Bí a bá lo òṣùwọ̀n níní-ẹ̀mí, ọ̀nà méjì gbòógì ni a le pín àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ onítàn Yorùbá sí. Àwọn ọ̀nà náà ni ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ẹlẹ́mìí àtí ẹ̀dá ìtàn àlọ́ aláìlẹ́mìí. Kí á tó máa ṣàlàyé nípa àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ̀nyí ní ọ̀kọ̀ọ̀kan, ó yẹ kí á tọ́ka sí àwọn àbúdá kan tó pa àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́pọ̀, yálà wọ́n jẹ́ ẹlẹ́mìí tàbí aláìlẹ́mìí. Kò sí ààlà kan gbòógì ní àárín àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ onítàn Yorùbá. Ènìyàn le kópa bíẹni pé ẹyẹni, kó hu ìyẹ́ lára kí ó sì máa fò bí àpẹẹrẹ. Eyí kò sì lè ṣẹlẹ̀ lójú ayé tòótọ́. Bákan náà ni ẹranko náà lè ṣe bí ènìyàn. Ìdí nìyẹn tí a fi rí ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ lápappọ̀ bí ẹ̀dá mérìíyìírí. Ìyẹn ni pé irú àwọn ẹ̀dá tí a kì í bá pàdé lójú ayé. Àpẹẹrẹ ni èwúrẹ́ tó sọ̀rọ̀ nínú ìtàn àlọ́ "Ìdí tí ewúrẹ́ kò ṣe sọ̀rọ̀ bí ènìyàn mọ́" (Ọ̀pádọ̀tun, 1994: 78). Ṣàṣà ni àlọ́ onítàn Yorùbá tí ẹranko tàbí àwọn ohun aláìlẹ́mìí ti jẹ yọ, tí wọn kò níí kó ipa bí ẹni pé ènìyàn ni wọ́n. Èyí fi ẹsẹ̀ ohun tí a ti sọ ṣíwájú múlẹ̀,nígbà tí a sọ̀rọ̀ nípa ibùdóìtàn àlọ́,pé ayé mérìíyìírí ni ayé inú ìtàn àlọ́;gbogbo ẹ̀dá ìtàn ibẹ̀ ló le kó ipa agbàyanu tí kò le kó lójú ayé gidi.

Àbùdá mìíràn tí ó tún pa àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ pọ̀ ni pé, ihà kan ṣoṣo ni àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ máa ń sábà ní. Bí ẹ̀dá ìtàn àlọ́ kan bá jẹ́ ẹ̀dá ìtàn rere ní ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn àlọ́, títí tí ìtàn àlọ́ náà yóó fi parí, ẹ̀dá ìtàn rere náà ni yóò jẹ́, tí yóò sì kérè ìwà rere rẹ̀. Bákan náà bí ẹ̀dá ìtàn kan bá jẹ́ òṣebi ní ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn àlọ́, títí tí ìtàn náà yóó fi parí, òṣebi náà ni yóò jẹ́, tí òun náà yóò sì kó èrè ìwà rẹ̀. Ní ojú ayé, ènìyàn kò rí báyìí, torí pé ènìyàn a máa yí ìwà padà. Lọ́pọ̀ ìgbà ni ó tilẹ̀ máa ń jẹ́ pé bí ènìyàn ti ni ibi tí ó dára sí ní ojú ayé, náà ni yóò ní ibi tí ó kòdára sí tàbí tí ó ti kù káàtó. Ènìyàn kì í sábàá dára tán pátápáta, bẹ́ẹ̀ ni ènìyàn kì í burú tán pátápáta. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi máa ń wí pé “Kò sí adára má nìí ṣùgbọ́n,” àti wí pé ọmọ burúkú ní ọjọ́ tirẹ̀ lọ́tọ̀. A lérò pé ìdí tí àwọn òǹpàlọ́ Yorùbá fi máa ń ṣe àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ wọn ní oníhà kan ni kí èrè ìwà ẹ̀dá ìtàn kọ̀ọ̀kan baà lè kún ojú òṣùwọ̀n, kí iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀, ìbáàṣe rere, tàbí búburú ó lè hàn ketekete.Kí ó lèhàn gbangba ìdí tí irú èrè ìwà tí ó bá gbà fi tọ́ sí i. Ìdí mìíràn ni pé wọn kò fẹ́ kí ìtàn náà dàrú mọ́ àwọn ọmọdé tí wọ́n fẹ́ fi àlọ́ kọ́ lẹ́kọ̀ọ́ lójú. Ohun tí ó jẹ àwọn òǹpàlọ́ Yorùbá lógún ni kí àwọn ọmọ, tí wọ́n jẹ́ olùgbọ́ wọnlè mọ ìwà rere yàtọ̀ sí ìwà ibi láti pínníṣín wọn.

Ọ̀nà tí wọ́n sì ń gbà ṣe èyí náà ni mímú kí ẹ̀dá ìtàn,tí ó jẹ́ ẹni rere ó ní ìwà rere látìbẹ̀rẹ̀ ìtàn títí dé ìparí, kí ẹ̀dá ìtàn tí ó jẹ́ òṣebi ó sì ní ìwà burúkú látìbẹ̀rẹ̀ títí dé òpin ìtàn. Bí wọ́n bá ṣe àmúlùmálà àwọn ìwà náà, ó lè dàrú mọ́ àwọn ìpẹ́ẹ̀rẹ̀ náà lójú, kí wọ́n sì pàdánù ẹ̀kọ́ tí a fẹ́ fi ìtàn náà kọ́ wọn.

### 4.1.1 Ẹlẹ́mìí tí ń mí

Àwọn ẹ̀dá ẹlẹ́mí tó ń mí sókè sódò, ni a ní lọ́kàn ní ibi, tí ohun mìíràn tí ó wà láàyè tí ó lè rìn kiri, tí a lè bí tí ó lè dàgbà, tí ó sì le kú bí ó bá yá ni a ní lọ́kàn níbí. Ènìyàn, ẹranko, ẹyẹ, kòkòrò, ẹ̀dá inú omí àti ẹbọra ni a ní lọ́kàn. Ènìyàn ni olórí àwọn ohun tí ó ní ẹ̀mí tó sì ń mí bẹ́ẹ̀. Báyìí náà sì ni ó sì ti rí nínú àlọ́ onítàn. Nínú àlọ́ onítàn, ó ṣe é ṣe kí ẹ̀dá ìtàn tí ó jẹ́ ènìyànpara dà di ẹranko tàbí kí ó tilẹ̀ ní àbùdá ẹranko tàbí ti ẹ̀dá mìíràn. Ẹranko náà lè yípadà di ènìyàn tàbí kí ó ṣe bí ènìyàn, ó le máa sọ̀rọ̀ bí ènìyàn. Bákan náà ni ẹbọra le yí padà di ènìyàn tàbí kí ó di ẹranko. Ohun tí à ńsọ ni pé kì í sí ààlà rigidi kan pàtó láàri àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́; gbogbo wọn ni í tílẹ̀ máa sọ̀rọ̀ bí ènìyàn.

#### 4.1.1.1 Ajẹméniyàn

Kò sí irú ẹ̀dá ènìyàn tí kò le jẹ́ ẹ̀dá ìtàn àlọ́. Ẹ̀dá ìtàn àlọ́ le jẹ́ ọkùnrin, ó le jẹ́ obìnrin, ó lè jẹ́ ọmọdé, ó sìlè jẹ́ àgbàlagbà. Ó le jẹ́ olówó, ó sì le jẹ́ tálákà. Kò sí ipò tí ènìyàn le dì mú nínú ayé tí àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ onítàn Yorùbá kò lè jẹ́. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, Ọba Aláràn-án nínú ìtàn ‘Ọba Aláràn-án àti Ẹyẹ Kìnkin jẹ́ ọkùnrin, ó sì tún jẹ́ ọba (Àpáta, A kò mọ ọdún ìgbéjáde: 3 – 5). Obìnrin ni Ìyá Alákàrà tí Ìjàpá ń jí ní àkàrà nínú ‘Ìjàpá àti Ìyá Alákàrà’ (Babalọlá, 1973: 20 – 25). Ó ṣe é ṣe kí ẹ̀dá ìtàn àlọ́ tó jẹ́

ènìyàn tó yíra padà sí nǹkan mìíràn bí ẹranko, òkúta àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ nínú àlọ́ onítàn Yorùbá. Àpẹẹrẹ èyí wáyé nínú ìtàn 'Ìjàpá Akítì àti àwọn Ará Ọ̀run' (Babalọlá, 1973: 83 – 91). Ọmọ Akítì tó jẹ́ ènìyàn nínú ìtàn yìí yíra padà di eṣinṣin láti le bá bàbá rẹ̀ lọ sí ọ̀dọ̀ àwọn ará ọ̀run tó ti ń ta ẹmu rẹ̀. Nínú àlọ́ olólórogún ni ẹ̀dá ìtàn tó jẹ́ ènìyàn pọ́nńbélé, tí í máa á jẹyọ dáradára. Bí a bá ti sọ pé orogún ni àwọn kan, a ti mọ̀ pé ènìyàn ni wọ́n máa jẹ́; Ìyálé àti Ìyàwó. Wọn yóò lọ́kọ, wọn sì lè bímọ tàbí kí wọ́n má bí. Ṣàṣà ni àlọ́ olólórogún tó jẹ́ pé ẹranko ni àwọn orogún náà, bí irúfẹ́ àlọ́ bẹ́ẹ̀ bá wà, kò wọ́pọ̀. Àwọn àpẹẹrẹ àlọ́ nínú èyí tí ènìyàn ti jẹ́ ẹ̀dá ìtàn ni ìtàn 'Ọba kan àti ọmọ rẹ̀ tó ya Odi', 'Tanímọ̀là àti Orogún rẹ̀ àti 'Awóbùnmi àti àwọn Òbí rẹ̀' (Ọ̀pádọ̀tun, 1994:18, 69 àti 75).

### 4.1.1.2 Ajẹmẹ́bọra

Àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ajẹmẹ́bọra pé orísìírísìí nínú àlọ́ onítàn. Àwọn kan le jẹ́ òkú ọ̀run tí wọ́n fẹ́ láti wá ran ènìyàn wọntí ó wà nínú ìṣorokan tàbí òmírà lọ́wọ́. Irú òkú bẹ́ẹ̀ le di ènìyàn, ẹranko tàbí ẹyẹ kí ó sì wá ran onítọ̀hún lọ́wọ́. Àpẹẹrẹ èyí ni ìtàn ọmọkan tí ń jẹ́ Àdíjátù Kẹkẹlúkẹ̀. Ọba gbé ìdánwò tó le fún Àdíjá pé bí ó bá le dá òun mọ̀ lẹ́yìn ọjọ́ keje tó ti pa ọba àti ìyàwó àti àwọn ìjòyè rẹ̀ ní ayò ní ààfin, òun yóò dá ilé àti ọ̀nà òun méjì fún un, bí kò bá le dá òun mọ̀, pípa ni òun yóò pa á. Ìyá rẹ̀ tó jẹ́ òkú ọ̀run ló di ẹyẹ tó ń kọrin pé ọba kọ́ ni ó dé adé owó àti pé ẹni tó múra bíi tálákà, tó gbékun lémú, tó sì wẹ̀wù àkísà ni ọba. Báyìí ni ọmọ náà ṣe yege ìdánwò tí a gbé fún un ṣe. Ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ajẹmẹ́bọra mìíràn a máa jẹ́ ẹbọra pọ́n-ńbélé. Àpẹẹrẹ èyí ni àwọn ará ọ̀run tí ó ń bá Akítì ra ẹmu nínú àlọ́ 'Ìjàpá Akítì àti àwọn Ará Ọ̀run' tí a tọ́ka sí lókè yẹn. Nígbà mìíràn, ẹbọra lè jẹ́ òrìṣà. Àpẹẹrẹ èyí ni Àrọ̀nì, Ọ̀sanyìn àti Ṣìgìdì tí wọ́n máa ń kópa gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn àlọ́. Nínú ìtàn àlọ́ 'Ìjápá l'óyún ìjàngbọ̀n' (Babalọlá, 1973: 78 – 82), ojúbọ Ọ̀sayìn, tí Yorùbá kà sí òrìṣà ewé àti egbò ni Ìjápá kú sí, ìdí sì nìyí tí wọ́n fi ń pa ìjàpá bọ Ọ̀sanyìn di òní olónìí. Ohun tí a fẹ́ fà yọ níbí ni pé Ọ̀sányìn tó jẹ́ ẹbọra kópa gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn àlọ́. Kókó kan tí a kò gbọdọ̀ má mẹ́nu bà ni pé gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ajẹmẹ́bọra, ipa mérìíyìírí ni wọ́n máa ń kó nínú àlọ́ onítàn torí pé ẹ̀dá ìtàn mérìíyìírí ni wọ́n.

### 4.1.1.3 Ajẹmẹ́ranko

Àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ajẹmẹ́ranko ni ó gbajúmọ̀ jùlọ nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá. Ìṣesí àwọn ẹranko wọ̀nyí yàtọ̀ síra. Bákan náà sì ni ìrísí wọn kò jọra wọn. Àwọn Yorùbá máa ń lo àǹfààní àlọ́ pípa láti pe àkíyèsí àwọn ọmọdé sí ìrísí àti ìṣesí àwọn ẹranko náà bí wọ́n ti ń ṣe ìmúlò wọn láti kọ́ wọn ní ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí. Kò sí ẹranko kan tí àwọn apàlọ́ Yorùbá kì í mú lò nínú àlọ́ onítàn wọn. Àmúlò àwọn ẹranko wọ̀nyí wọ́pọ̀ nínú àwọn àlọ́ tó ń sọdí abájọ. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, 'Ìdí abájọ tí Kìnnìún fi ń bú', 'Ìdí abájọ tí ọrùn ògòngò fi gùn tó bẹ́ẹ̀' àti 'Ìdí abájọ tí adìẹ fi ń ṣa ilẹ̀ jẹ' (Àmọ̀rí, 1978: 1, 3 àti 5). Nípasẹ̀ irú ìtàn àlọ́ tí a fi ń sọ ìdí abájọ bẹ́ẹ̀ ni

wọ́n ń kọ́ àwọn ọmọdé ní ẹ̀kọ́ nípa ìrísí àti ìṣesí àwọn ẹranko, ẹyẹ, kòkòrò àti àwọn ohun mìíràn tí ń bẹ ní àyíká wọn.Ohunkan tí akò gbọdọ̀mójú fò ni pé wọn a máa fi ìwà àti ìṣe èniyàn láwùjọ tí kì í ṣe ti àwọn ẹranko wọ̀nyí wọ̀ wọ́n. Gbogbo wọn ni ó máa ń sọ̀rọ̀ bí ènìyàn bí a ti tẹ̀ka sí i. Wọn a tilẹ̀ máa díje láti gbé arẹwà ọmọge níyàwó. Àpẹẹrẹ ni ìtàn àlọ́ Àkùkọ tí ókéré jù lọ nínú àwọn ẹranko yòókù bí i Erin, Efọ̀n, Kìnìhún àti Ẹkùn tí wọ́n jìjọ díje oko ríro láti fẹ́ Ariẹgẹ, awẹ́lẹ́wà ọmọge kan. Àkùkọ ni ó gba ipò kìn-ín-ní, ó sì di ọkọ Ariẹgẹ.

Ìjàpá ni ẹranko tí ó gbajúmọ̀ jùlọ nínú àlọ́ onítàn Yorùbá lápapọ̀. Ìgbàgbọ́ Yorùbá nínú àlọ́ nípa ẹranko yìí ni pé, ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́ ni ó jẹ́. Wọn a sì máa fi èyí kì í pé ìjàpá ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́. Wọn a máa sọ pé ọ̀rọ̀ gbogbo kì í sé lórí alábahun bí a ti sọ ṣaájú. Gẹ́gẹ́ bí òṣebi ẹ̀dáìtànni àwọn apàlọ́ Yorùbá máa ń ṣe àfihàn alábahun, tí a tún mọ̀ sí ìjàpá nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àlọ́ onítàn wọn.Ẹ̀san ìwà burúkú rẹ̀ yìí náà ni wọ́n sì máa ń fi kọ́ àwọn ọmọdé lẹ́kọ̀ bí a ti sọ tẹ́lẹ̀. Nígbà míràn tí Ìjàpá bá mú ìwà àìdára rẹ̀ jẹ nínú àlọ́, ó máa ń sábàá jẹ́ pé láti ara ẹdá ìtàn míràn nínú àlọ́ náà ni wọ́n ti fẹ́ kí àwọn ọmọ kọ́ ẹ̀kọ́ ni. Bí àpẹẹrẹ, nínú ìtàn 'Ìjà láàrin Ìjàpá àti Erin' (Babalọlá 1979: 22 – 27), Ìjàpá fi ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ rẹ̀ na Erin ní àlù-yàgbẹ́-sára,àlù-fọ́-lórí àti àlù-bolẹ̀ nínú ìdíje ìjà. Láti ara Erin, ti ó tí ó fojú tẹ́ńbẹ́lú Ìjàpá, tí ó sì ń ṣegbéraga ni apàlọ́ ti fa ẹ̀kọ́ yọ fún àwọn ọmọdé wí pé, ọgbọ́n ju agbára lọ, àti wí pé ìgbéraga kò dára. Nínú ìtàn àlọ́ 'Ìjàpá mú Erin Wọ̀lú Láàyè' (Babalọlá 1979: 28 – 35)níbi tí Ìjàpá ti fi àkàrà olóyin àti ọ̀rọ̀ dídùn tan Erin wọ ìlú, tí ó sì kó sínú ọ̀fìn tí wọ́n ti gbẹ́ sílẹ̀ dè é, tí wọ́n sì fi í rúbọ, wọ́n fẹ́ kí ọmọdé kọ́ ẹ̀kọ́ lára Erin, pé kí wọ́n máa ṣọ́ra fún àwọn ẹlẹ̀tàn ènìyàn, àti àtẹnujẹ; kí wọ́n sì má fẹ́ràn oúnjẹ àdídùn jù bí ó ti yẹ lọ. Òwe Yorùbá kan sọ pé "Òwò tí àdá mọ̀ ní í ká àdá léyín, ohun tí a bá ń jẹ ní í pani." Bákan náà ni pé láti ara Ẹlẹ́dẹ̀ ni apàlọ́ ti fẹ́ kí ọmọdé kọ́ ẹ̀kọ́ pé inú fùfù kò dára, kí a máa ní sùúrù kí àre ẹni má báà di ẹ̀bi, nínú àlọ́ onítàn 'Ìjàpá yá Owó Àyáàsan Lọ́wọ́ Ẹlẹ́dẹ̀' (Babalọlá, 1979: 61 – 65).Nínú ìtàn àlọ́ náà ni Ẹlẹ́dẹ̀ ti fi ìbínú gbé ọlọ Yánníbo,ẹni tí ó fi í gún lágidi sọnù, láì mọ̀ pé Ìjàpá, tí Yanníbo fi ẹ̀yìn rẹ̀ lélẹ̀, ló díbọ́n bí ọlọ. Yanníbo, tí kò ti sọ̀rọ̀ tẹ́lẹ̀ figbe ta, ó lọ́ṣọ mọ́ Ẹlẹ́dẹ̀ lọ́rùn pé kí ó wa ọlọ òun fún òun ní kíákíá. Tòun tẹnu rẹ̀ ni Ìjàpá padà wọlé, tí òun náà sì gbè lẹ́yìn Yánníbo pé kí Ẹlẹ́dẹ̀ lọ wá ọlọ ìyàwó òun wá, kí ó tó wá gba owó rẹ̀. Ẹlẹ́dẹ̀ kò rí ọlọ mọ́, ó sì pàdánù owó rẹ̀. Ọlọ náà ni Ẹlẹ́dẹ̀ ń wá kiri láti ọjọ́ náà títí di òní tí ó fimú túlẹ̀ kiri. Àwọn ẹ̀ranko mìíràn tí wọ́n sábàá máa ń jẹ yọ nínú àlọ́ onítàn Yorùbá ni kìnìhún, ajá, ìgbín, ọ̀bọ/ààyá, ewúrẹ́, adìyẹ, ọ̀nì, ẹfọ̀n, kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀, ìkookò, ẹkùn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 4.1.2 Aláìlẹ́mìí

Ẹ̀dá ìtàn aláìlẹ́mìí nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá ni ẹ̀dá bí ewéko, igi oko, odò, òkè, àpáta, òkùnkùn, iná, ọ̀sán, alẹ́, òjò, afẹ́fẹ́, ìjì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àìní àbùdá mímí sókè sódò gan-an ni à ń tọ́ka sí ní ibí tí ó mú wọn yàtọ̀

s'àwọn tí a ti ssrọ̀ bá lókè. A lè pín àwọn ohun aláìlẹ́mìí tí à ń sọ yìí sí àwọn tó jẹ mọ́ ewéko (ajẹméwéko), àwọn tó jẹ mọ́ òkúta (ajẹmókùúta) pẹ̀lú àwọn ohun àfojúrí mìíràn àti àwọn tó jẹ mọ́ ohun àìfojúrí tàbí ohunafòyemọ̀. Irú àwọn ohun afòyemọ̀ wọ̀nyí ni ayọ̀, ẹ̀rù, afẹ́fẹ́, ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye. Ó yẹ kí a tọ́ka sí i wí pé ní ojú ayé ni àwọn ohun wọ̀nyí ti jẹ́ aláìlẹ́mìí ṣá o. Ní inú àwọn àlọ́ Yorùbá bí ènìyàn ni wọ́n máa ń ṣe, tí wọ́n sì máa ń hùwà. Bí a bá rántí, bákan náà ni àwọn ẹ̀dá ìtàn ajẹmẹ́ranko náà máa ń ṣe bí ènìyàn. Ìdí kì-ín-ní tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ní pé ayé mérìíyìírí, tí ó kún fún oríṣiríṣi ìṣẹ̀lẹ̀ kàyéfì, ni àyé inú àlọ́ onítàn. Ìdí kejì ni wí pé àrokò nípa ìṣe àti ìhùwàsí ènìyàn láwùjọ ni wọ́n ń fi gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn náà pa.

## 4.1.2.1 Ajẹméwéko

Ewéko a máa jẹ́ ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ onítàn Yorùbá. Ewéko yìí lè jẹ́ igi eléso jíjẹ bíi ọsàn àgbálùmọ̀ àti ọ̀pẹ, igi tí kò léso, bíi ìrókò àti ọ̀ganwó tàbí ìtàkùn bíi igbá. Nígbà mìràn, èso ara igi tàbí ìtàkùn náà le jẹ ẹ̀dá ìtàn. Àpẹẹrẹ èyí sì ni Igbá, tí ó sọ̀rọ̀ tí ó sì tún lé Ìjàpá nínú ìtàn àlọ́ 'Ìjàpá,Àgbò àti Igbá" (Babalọlá, 1979: 60-64). A rí àpẹẹrẹ Ìrókò àti Ọ̀pẹ nínú itàn àlọ́ 'Ìjàpá àti Àgàràmọ̀kù.' Nígbà tí Ìjàpá fẹ́ jí ẹ̀bẹ, tí Ìyá ìyàwó rẹ̀ ní kí ó bá òun gbé fún Yanníbo, ìyàwó rẹ̀ jẹ lọ́nà ilé, ọ̀dọ̀ igi Ìrókò ni ó kọ́kọ́ yà kí ó tó ya ọ̀dọ̀ igi Ọ̀pẹ láti jókòó jẹ ẹ̀bẹ náà.Àwọn igi méjèèjì yí béèrè lọ́wọ́ Ìjàpá pé ṣé Ìjàpá ó fún àwọn ọmọ wọn ní àṣáro jẹ. Ṣùgbọ́n nítorí àdánìkànjẹ tí Ìjápá fẹ́ jẹ ẹbẹ náà àti pé ọmọ àwọn méjèèjì ti pọ̀ jù ní ojú rẹ̀, tìrókò meje, ti Ọpẹ márùn-ún, ni ó fi kọ̀ fún wọn tí ó sì ṣí lọ sí ọ̀dọ̀ ẹlòmíràn tí ọmọ rẹ̀ kò pọ̀.Ohun tí à ń pe àkíyèsí sí ni pé àwọn igi méjèèjì yí ni wọ́n ń sọ̀rọ̀ bí ènìyàn nínú ìtàn àlọ́ náà.

4.1.2.2 Ajẹmókùúta àti àwọn ohun àfojúrí/ àrídìmú mìíràn

Ẹ̀dá ìtàn lè jẹ́ oríṣìíríṣìí òkúta bí akọ òkúta, àpáta, ìdàrọ́ tàbí yangí. Kì í ṣe òkúta nìkan ló le jẹ́ ẹ̀dá ìtàn àlọ́ àfojúrí/ àrídìmú; odò, iná àti òjò náà le jẹ́ irú ẹ̀dá ìtàn bẹ́ẹ̀. Gbogbo àwọn irú ẹ̀dá ìtàn wọ̀nyí náà ni a máa fi ìwà èniyàn wọ̀ bí ẹ̀wù nínú àwọn àlọ́ Yorùbá, tí ó jẹ́ pé gbogbo ohun tí ènìyàn ń ṣe ni àwọn náà ń ṣe. Nínú àlọ́ onítàn tí à ń sọ bọ, níbi tí ìjàpá ti ń wá ibi tí yóò ti dá jẹ ẹ̀bẹ, lẹ́yìn tí ó kúrò lọ́dọ̀ Ìrókò àti Ọ̀pẹ, ọ̀dọ̀ Àpáta tí ó jẹ́ pé ọmọ mẹ́ta péré ló bí ni ó lọ. Ibẹ̀ ni ó sì ti jẹ ẹ̀bẹ náà. Ṣùgbọ́n ìwà ànìkànjọpọ́n rẹ̀ kò jẹ́ kí ó jẹ ẹbẹ kù sílẹ̀ fún àwọn ọmọ Àpáta, ìdí rẹ̀ sì lẹ̀ pa mọ́ orí Àpáta tí kò fi lè dá dìde mọ́. Nínú àlọ́ onítàn míràn, Iná àti Òjò jìjọ ń duÀgbado fẹ́ ní ìyàwó. Àwọn méjèèjì sì jọ fẹnu kò sí pé ẹni tí ó bá lágbára láti borí ẹnìkejì ni kí wọn gbà pé Òjò já mọ́ lọ́wọ́. Iná ni ó kọ́kọ́ dé tí ó sì ki Àgbàdo mọ́lẹ̀. Àgbado, tí ó jẹ́ pé Òjò ni ó nífẹ̀ẹ́ sí jù nínú àwọn méjèèjìki orin bọnu láti ké sí Òjò.Nígbà tí Òjò dé,ó fi gbogbo agbára rẹ̀ rọ̀, ó pa oró iná kú fi-ín fin-ín, ó sì gbé Àgbàdo níyàwó. Síwájú sí i, nínú ìtàn àlọ́ mìíràn ni Ayé àti Ọ̀run ti jìjọ ń ṣe ọ̀rẹ́(Adégòkè, 2006: 37 – 38). Àwọn méjèèjì pa eku kan, eku náà sì di

ìjà. Ọ̀run bínú padà lọ sí ọ̀run, òjò kò sì rọ̀ mọ́. Bákan náà nínú àlọ́ 'Pankoko' (Apata, a kò mọ ọdún ìgbéjáde: 34 – 36), lára àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ náà tí Pankoko, òburẹ́wà ọmo tí ìyá rẹ̀ yọ́ fi sílẹ̀ lóun nìkan tí ósì kó àwọn arẹwà ọmọ rẹ̀ mẹ́fà yókù sá lọ,fi orin bá sọ̀rọ̀ pé kí wọn ó yàgò lọ́nà nígbà tí ó ń wá ìyá rẹ̀ lọ, ni Igbó dídí, Odò àti Òkè. A ó rí i pé Igbó dídí, Odò àti Òkè jẹ́ ẹ̀dá ìtàn aláìlẹ́mìí àfojúrí/àrídìmú. Nínú ìtàn àlọ́ náà, wọ́n gbọ́ ohun tí Pankoko fi orin bá wọn sọ, wọ́n sì ṣe ohun tí ó fẹ́ fún un láti ràn an lọ́wọ́ nípa yíyàgò lọ́nà kí ó lè kọjá láìsí ìdíwọ́. Ìmọ̀sílára ti wọ́n fi hàn sí ẹ̀bẹ̀ Pankoko yìí ni ó fi hàn gbangba pe wọ́n ti fìwà wọ̀ wọ́n bí ènìyàn.Gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn yókù tí a ti mẹ́nu bà ni wọ́n fi àbùdá enìyàn kan tàbí òmíràn wọ̀ lẹ́wù kí wọn lẹ̀ ní àfijọ ènìyàn.

### 4.1.2.3 Àìfojúrí/Afòyemọ̀

Àwọn ẹ̀dá ìtàn àìfojúrí/afòyemọ̀ ni àwọn ẹ̀dá ìtàn alọ́ tí a kò le fi ojú rí, ṣùgbọ́n tó jẹ́ pé òye nìkan ni a le fi mọ̀ pé wọ́n wà. Àpẹẹrẹ àwọn ẹ̀dá ìtàn báyìí ni Ikú, Afẹ́fẹ́, Ẹ̀rù, Ìbànújẹ́, Ayọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ ìtàn àlọ́ kan nínú èyí tí òòrùn àti afẹ́fẹ́ tí jọ díje láti mọ ẹni tó lágbára jùlọ nínú àwọn méjèèjì. Nínú ìdìje yìí, ọkùnrin kan tí ó jókòó ní abẹ́ igi jẹ́jẹ́ ara rẹ̀ ni àwọn ẹ̀dá méjèèjì fi dán agbára wọn wò. Òfin tí wọ́n fi lélẹ̀ ni pé, ẹni tó bá ti le gba ẹ̀wù lọ́rùn ọkùnrin náà ni ó lágbára ju èkejì lọ. Afẹ́fẹ́ ni ó kọ́kọ́ dán agbára rẹ̀ wò. Ó fi gbogbo agbára fẹ́, ṣùgbọ́n kò rí ẹ̀wù gbà lọ́rùn ọkùnrin náà. Òòrùn dán agbára rẹ̀ wò, ó sì rí ẹ̀wù gbà lọ́rùn ọkùnrin ọ̀hún, afẹ́fẹ́ sì gba òòrùn ní ọ̀gá (Adégòkè, 2006:56 – 57); Afẹ́fẹ́ nìkan ni ẹ̀dá ìtàn àìfojúrí tàbí àfoyemọ̀ nínú àwọn ẹ̀dá ìtàn méjèèji náà ṣá, a lè fojú rí òòrùn. Bákan náà ni a rí Ẹ̀rù gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn àìfojúrí tàbí àfoyemọ̀ nínú ìtàn àlọ́ Ajalugbagba (Àpáta a kò mọ ọdún ìgbéjáde: 39 – 40). Ẹ̀rù gbé àbúrò Ajalugbagba lọ ní òru nígbà tí gbogbo ilé ti sùn. Nígbà tí ó gbé e dé ìkórìta oko ẹ̀gbọ́n rẹ̀ ni òun gan-an alára tó ta jí tí ó sì figbe orin bọ ẹnu. Nígbà tí àpá ẹ̀gbọ́n rẹ̀ kò ká Ẹ̀rù ó fi orin ké sí àwọn ajá rẹ̀ mẹ́ta: Òkémọkéréwú, Ọ̀sọ́pàkàgbemì àti Ọ̀gbálẹ̀gbáràwé. Nígbà tí wọ́n dé wọ́n palẹ̀ Ẹ̀rù mọ́ nílẹ̀ féfé. Látìgbà náà ni Ẹ̀rù kì í ti i gbéèyàn mọ́, tí ó jẹ́ pé ókàn maa ń ba ènìyàn ni.

### 4.2.0 Ìfiwàwẹ̀dá

Bí oníṣẹ́ ọnà aláwòmọ̀lítíréṣọ̀ ṣe dáṣọ ìwà wọ àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ni ìfiwàwẹ̀dá. Nínú àlọ́ onítàn Yorùbá, àwọn apàlọ́ a máa dáṣọ ìwà wọ àwọ́n ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ lọ́nà tí yóò mú kí àwọn tí kì í ṣe ènìyàn dà bí ènìyàn. Nínú àlọ́ onítàn gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ lókè, ẹ̀dá ìtàn le jẹ́ ènìyàn. Bí ẹ̀dá ìtàn bá sì jẹ́ ènìyàn, ó pọn dandan kí apàlọ́ dáṣọ ìwà tí ó fẹ́ kó hù wọ̀ ọ́. Èyí ló fà á tí àwọn ìyálé nínú àlọ́ olórogún mìíràn fi le jẹ́ òṣebi, tí ìyálé nínú àlọ́ mìíràn yóò sì jẹ́ ènìyàn rere, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kí ìyálé jẹ́ ẹ̀dá aṣere kò wọ́pọ̀ nínú àlọ́ onítàn Yorùbá lápapọ̀. Bí ẹ̀dá ìtàn bá sì jẹ́ ẹranko tàbí ohun aláìlẹ́mìí, apàlọ́ gbọ́dọ̀ dáṣọ ìwà wọ̀ wọ́n, kí ó sì mú wọn hùwà gẹ́gẹ́ bí ènìyàn tàbí bí ẹranko tí a fẹ́ láti fi ìṣe rẹ̀ hàn. Yàtọ̀ sí pé àwọn ẹ̀dá ìtàn

inú àlọ́ ń sín èniyàn jẹ, àṣà àwùjọ adáríhurun ní ilẹ̀ Yorùbá ni wọ́n máa ń ṣe àfihàn. Wọ́n kì í ṣe àfihàn àṣà tó ṣàjèjì. Ìdí nìyẹn tí a fi sọ pé àrokò nípa èniyàn láwùjọ ni wọ́n ń fi gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ pa. Ohun tí ó jẹ́ kí èyí rí bẹ́ẹ̀ ni pé àfojúsùn Yorùbá lórí àlọ́ onítàn ni láti kọ́ àwọn ọmọdé ní ẹ̀kọ́ ìwà, àṣà àti ìṣe àwùjọ wọn. Láti fi ìwà wọ ẹ̀dá ìtàn àlọ́, àwọn apàlọ́ máa ń ṣe àmúlò orúkọ, ìrísì, ìṣesí àti ìhùwàsí.

## 4.2.1 Orúkọ

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní orúkọ ọmọ ni ìjánu ọmọ. Wọ́n tún máa ń sọ pé, Orúkọ a máa roni, oríkì a sì máa rònìyàn. Àwọn apàlọ́ Yorùbá máa ń ṣe àmúlò àwọn èrò nípa orúkọ wọ̀nyí nínú ìfìwàwẹ̀dá inú àlọ́. Ìdí nìyí tí orúkọ tí wọ́n fún ẹ̀dá ìtàn àlọ́ máa fi ń nípa lórí ìfìwàwẹ̀dá wọ́n nínú àlọ́ onítàn Yorùbá. Àwọn irúfẹ́ orúkọ tí a lè bá pàdé nínú àlọ́ onítàn ni orúkọ alárokò, orúkọ ipò láwùjọ, orúkọ ajẹmọ́rìísí àti orúkọ ìsọmọ.

### 4.2.1.1 Orúkọ Alárokò

Àwọn orúkọ kan máa ń jẹyọ nínú àlọ́ onítàn tí wọ́n máa ń fi ń pàrokò nípa ìwà, tàbí ìṣeẹ̀dá ìtàn tí a fún ní orúkọ náà. Irú àwọn ẹ̀dá ìtàn náà máa ń sábàá jẹ́ ẹ̀dá ìtàn pàtàkì nínú àlọ́ náà. Lọ́pọ̀ ìgbà ló jẹ́ pé àwọn ẹ̀dá ìtàn olórúkọ àrokò yìí ló sábàá máa ń jẹ́ olú ẹ̀dáìtàn àlọ́ tí wọ́n bá ti jẹ yọ. Nígbà mìíràn, wọ́n le jẹ̀ amòye kan tí yóó gba ọ̀nà kan ran olú ẹ̀dá ìtàn lọ́wọ́ tàbí òṣebi ẹ̀dá ìtàn kan tí yóò ṣàkóbá fún olú ẹ̀dáìtàn àlọ́. Kì í ṣe ẹ̀dá ìtàn àlọ́ tó jẹ́ èniyàn níkan ló lè ní orúkọ àrokò nínú àlọ́ onítàn Yorùbá. Gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ mìíràn náà le ní orúkọ alárokò. Àpẹẹrẹ orúkọ alárokò tí a fún àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́tí wọ́n jẹ́ èniyànnìwọ̀nyí: ẸniỌlọ́runòpa, Ọlọ́rànmọdùn, Ṣooreṣá, múwá,Afigbáṣoyún, Atikékerélọ́gbọ́n, ṣewèrègbọ́lọgbọ́ńtà,Tanímọ̀la,Akúrúńtegún,Ọgbọ́nlayé, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àpẹẹrẹ orúkọ alárokò fún àwọn ẹ̀dá ìtàn tí kì í ṣènìyàn nínú àlọ́ onítàn ni ẹyẹ Kín-ìn-rínjigbin,ẹyẹ Kìn-ìn-kin, Òkémọkéréwú, Òsọ́pàkàgbemì àti Ògbálẹ̀gbáràwé tí ó jẹ́ orúkọ àwọn ajá ọdẹ Ajalugbagba nínú ìtàn àlọ́ tí a ti mẹ́nu bànáà jẹ́ àpẹẹrẹ irú orúkọ yìí.

### 4.2.1.2 OrúkọAjẹmọ́ Ipò Láwùjọ

Ẹ̀dá ìtàn àlọ́ le máa jẹ́ orúkọ ipò kan láwùjọ. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà a kì í dárúkọ àbísọ ẹ̀dá ìtàn tí a bá fún ní irú orúkọ yìí. Dípò kí á dárúkọ àbísọ rẹ̀, a ó fi orúkọ ipò tàbí iṣẹ́ rẹ̀ láwùjọ pè é. Àpẹẹrẹ orúkọ ipò tí ẹ̀dá ìtàn le jẹ́ ni Ọba, Babaláwo, Ẹrú ọba, Ìyáálé, Ìyàwó, Ìyá, Bàbá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nígbà míràn wọn a máa dárúkọ oyè ọba ilẹ̀ Yorùbá tí a mọ̀ bí i Eléjìgbò (Ọnàsànyà, 1973), Olómù (Àpata a kò mọ ọdún ìgbéjáde.) Onídèrè(Ọ̀pádọ̀tun (1994). Nínú ìtàn àlọ́ ‘Ìyàwó, Ṣíyín fún mi wò’ (Ọ̀pádọ̀tun, 1994: 90-91) àti ‘Ìjàpá àti Àáyá Onírùméje’ (Babalọlá,

1973:130), a kò dárúkọ àbísọ àwọn ọba tó jẹ́ ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ wọ̀nyí, dípò kí á dárúkọ wọn, a pè wọ́n ní Ọba. Nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àlọ́ olórogún, a kì í sábàá dárúkọ àwọn orogún wọ̀nyí. Kàkà kí á dárúkọ wọn, a máa ń pè wọ́n ní orúkọ ipò wọn ní ilé ọkọ (Ìyálé tàbí Ìyàwó). Ṣùgbọ́n ṣá, a rí àwọn àlọ́ onítàn kọ̀ọ̀kan tí a ti dárúkọ àbísọ àwọn orogún wọ̀nyí. Nínú Ọ̀pádọ̀tun (1994:86-87), Ìlẹ́rẹ́ ni ìyàwó tí ìyálé rẹ̀ Ìlósùn parọ́ mọ́ pé ó fọ́ ọpọ́n. Ohun tí a lérò pé a kì í fí dárúkọ àwọn ẹ̀dá ìtán wọ̀nyí, tí a fi ń dárúkọ ipò wọn ni pé ipa tí a fẹ́ kí wọ́n kó nínú àlọ́ náà ni ó ṣe pàtàkì sí àwọn apàlọ́ Yorùbá ju ìgbékalẹ̀ ẹ̀dá ìtàn náà lọ. Láti inú ipa tí àwọn ẹ̀dá ìtàn náà bá kó ni wọn óò ti fa ẹ̀kọ́ tí wọ́n fẹ́ kọ́ àwọn ọmọ náà jáde. Ẹ̀kọ́ yẹn sì ni ohun pàtàkì jù lọ tí wọ́n fẹ́ kí wọn mọ̀.

### 4.2.1.3 Orúkọ Ajẹmọ́ Ìrísí

Àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ máa ń jẹ́ orúkọ tó jẹ mọ́ ìrísí wọn. Ìrísí yìí le jẹ́ àléébù kan pàtàkì tí ó wà ní ara wọn. Nígbà mìíràn, orúkọ náà sì le jẹ́ àbùdá ẹwà tó wà lára ẹ̀dá ìtàn. Orí àbúdá yìí náà sì ni a sábàá máa ń gbé ìfìwàwẹ̀dá wọn lé. Nínú àlọ́ kan, baba kan bí ọmọ méjè, ó ní kí àwọn ọmọ náà lọ mú iná wá ní ọ̀dọ̀ bàbá Eléyín gan-n-gan. Kàkà kí àwọn ọmọ náà kí bàbá Eléyín gan-n-gan, eyín rẹ̀ ni wọ́n fi ń bú u. Èyí ló jẹ́ kí ó fi eyín rẹ̀ gan-n-gan náà ṣá àwọn ọmọ méjèèje pa ní ọ̀kọ̀ọ̀kan. Bákan náà ni ìtàn 'Ìjàpá, Ìgbín àti Abuké Ọṣin' (Babalọlá, 1973: 103-106). Abuké Ọsìn nínú ìtàn náà suké, èyí ni a sì fi pè é. Nínú àlọ́ onítàn 'Aláṣejù ìyàwó Ọba Ejìgbòmẹkùn' Ẹwà ni orúkọ orékelẹ́wà ìyàwó tí ọba Eléjìgbò fẹ́ ẹ́ fi ṣaya Ọnàsànyà (1973:1 – 9).Nínú àlọ́ mìíràn Ìyá ọlọ́mú rọ̀rọ̀ni a peobìnrin tí ó wá ń gbé oúnjẹ àwọn ọmọdé méjì, tí wọ́n jẹ́ tẹ̀gbọ́ntàbúrò kan jẹ nígbà tí àwọn òbí wọn kò bá sí nílé. Bákan náà ni awọn apàlọ́ Yorùbá a máa lo ohun kan nípa ìrísí láti sọ àwọn ẹbora tàbí iwin ní orúkọ ìdámọ̀ nínú àlọ́ onítàn wọn. Iwin olóri mẹ́ta, mẹ́rin sí méje tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ lè wà nínú ìtàn àlọ́, bẹ́ẹ̀ ni a lè rí Ọ̀sanyìn ẹlẹ́sẹ̀ kan, ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́ta, mẹ́rin, márùn-ún ati bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ nínú àlọ́ onítàn. Lákòótán, ohun kan tàbí òmíràn nípa ìrìsí àwọn ẹ̀dá ìtàn tí a fi ṣe àpẹẹrẹ wọ̀nyí ni a fi sọ wọ́n ní orúkọ, tí a fi dá wọn mọ̀ nínú àwọn àlọ́ onítàn tí wọ́n ti sú yọ.

### 4.2.1.4 Orúkọ Ìsọmọ

Orúkọ ìsọmọ ni gbogbo orúkọ tí a lè sọ ọmọ ní ìbámu pẹ̀lú àwọn àṣà, ẹ̀sìn, iṣẹ́, ipò ìbí rẹ̀ tàbí àwọn ohun tí ó ṣẹlẹ̀ lásìkò tí a bí i. Irú orúkọ bẹ́ẹ̀ le jẹ́ àmútọ̀runwa, àbísọ, oríkì tàbí ìnagijẹ/ àlàjẹ́ nígbà míràn. Kò sí èyí tí àwọn apàlọ́ Yorùbá kò lè mú lò. Àpẹẹrẹ àwọn orúkọ àbísọ ẹ̀dá ìtàn àlọ́ onítàn Yorùbá ni Awóbùnmi, Lẹ́yẹníbi, Mopé (Ọ̀pádọ̀tun, 1994) àti Fágoróyè. A rí orúkọ àmútọ̀runwá bí i Táíwò, Kẹ́hìndé,Òjó (Fújà, 1967),àti Ìgè (Àpáta, A kò mọ ọdún ìgbéjáde). Orúkọ oríkì bí i Àjàó àti Àkànó náà lè jẹ yọ nínú àlọ́ onítàn (Fújà 1967). Orúkọ inagijẹnáà a máa wáyé dáadáanínú àlọ́ onítàn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ orúkọ alárokò tí a ti mẹ́nu bà ṣaájú náà ni a tún lè rí bí ìnagijẹ. Bí àpẹẹrẹ, a tilẹ̀ sọ ní pàtó pé Òjó ni

orúkọ Aṣewèrègbọlọ́gbọ́ntà, àti pé nítorí ọgbọ́n inú rẹ̀ ni àwọn ará ìlú rẹ̀ fi ń pè é ni ìnagijẹ náà (Ọ̀pádọ̀tun 1994: 60). A là á yé wa bákan náà pé iwà lílé ẹ̀dá ìtàn tí a pè ní Jàmpàkò nínú ìtàn 'Jàmpàkò Kó Àìsinmi àti Àìrójú bá Ìlú Páńda' ni ó mú kí wọ́n máa da orúkọ rẹ̀ pè bẹ́ẹ̀.Síwajú sí i, a jẹ́ kí ó yé wa nínú àlọ́ onítàn 'Títílọpẹ́' wí pé ọ̀rọ̀ tí olú ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ náà fẹ́ràn láti máa sọ nígbà gbogbo pé "Títílọpẹ́ ni Olúwa!" ni ó mú kí wọ́n máa pè é ní Títilọpẹ́. Bẹ́ẹ̀ ni ó sì jẹ́ pé ìyàn tí ó lé ẹ̀dá ìtàn tí wọn pè ní Ẹniìyàn dé ọ̀dọ̀ Àná, Ọ̀ní àti Ọ̀la ni ó mú kí wọn máapè é ni orúkọ náà, pàápàá nígbà tí kò lè sọ orúkọ ara rẹ̀. (Ọnàsànyà, 1973: 38, 20, 50)Ìnagijẹ ni a le ka àwọn orúkọ náà sí.

Ohun kan tí ó yẹ kí á mẹ́nu bà, nínú fífún àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ní orúkọ ìsọmọ, pàápàá ti àmútọ̀runwá, àbísọ, àti oríkì ni péìtumọ̀ àwọn orúkọ náà lè má ní ipa dàbí alárà lórí ìfìwàwẹ̀dá àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ tó ń jẹ́ àwọn orúkọ náà. Fífún àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ní orúkọ àbísọ lè jẹ́ kí àwọn ọmọdé rò pé òtítọ́ ni ìtàn náà tórí ìṣewẹ́kú àwọn orúkọ náà pẹ̀lú orúkọ ní àwùjọ. Ìtumọ̀ orúkọ ìnagijẹ ní tirẹ̀ a máa ní ipa lórí ìfìwàwẹ̀dá gẹ́gẹ́ bí àlaàyé tí a ti ṣe. Bí ó ti máa ń ní ipa náà kò yàtọ̀ sí tí orúkọ alárokò. A tilẹ̀ le rí wọn gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan náà.

### 4.2.1.5 Orúkọ Àwọn Ẹ̀dá Ìtàn tí kì í ṣe Ènìyàn

Níwọ̀n ìgbà tí ayé inú àwọn ìtàn àlọ́ Yorùbá ti jẹ́ mérìíyìírí, kò yàwá lẹ́nu pé àwọn ẹ̀dá ìtàn tí kì í ṣe ènìyàn wọ́pọ̀nínú wọn. Gẹ́gẹ́ bí ati fi hàn ṣaájú, àwọn ẹbọra, bí i òkú ọ̀run, iwin, ọ̀rọ̀àti òrìṣà pàápàá a máa jẹ yọ nínú àwọn àlọ́ onítàn Yorùbá. Bí a ti sọ tẹ́lẹ̀, àwọn ẹranko, ẹyẹ, kòkòrò àti ohun aláìlẹ́mìí bí i igi, apáta náà a máa fara hàn nínú àlọ́ onítàn Yorùbá. Orúkọ tí a mọ̀mọ́ púpọ̀ nínú wọn ní ojú ayé náà ni a fi máa ń pè wọn nínú àlọ́ onítàn bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọn ń sọ̀rọ̀, wọ́n sì ń ṣe bí ènìyàn. Ọ̀sanyìn ni òrìṣà tí ó wọpọ̀ jù nínú àwọn àlọ́ Yorùbá, Ọ̀sanyìn náà ni wọn sì máa ń pè é, ṣùgbọ́n wọ́n tún lè ní ẹlẹ́sẹ̀ kan, mẹ́ta, mẹ́rin, márùn-ún, mẹ́fà, méje àti bẹ́ẹ̀, bẹ́ẹ̀ lọ. Yemọja, Olúwẹri àti Olókun tún ni àwọn òrìṣà omi, odò àti ibú tí ó wọ́pọ̀ nínú àlọ́ onítàn Yorùbá. Orúkọ tí wọn sì máa ń pè wọ́n nínú àlọ́ náà nìyẹn. Bákan náà ni àwọn ẹranko bí i Erin, Ẹkùn, Ìjàpá, Ẹfọ̀n, Ehoro; ẹyẹ bí i Igún, Àgbìgbò, Ògòǹgò, Àdán, Ẹyẹlé; kòkòrò bí i Èèrà, Ìkamùdù, Aáyán, Kaninkanin, Agbọ́n àti àwọn igi oko bí i Ọpẹ, Ìrókò, Ọgànwó, Ẹlú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nígbà míràn wọn a máa lo àwọn àpèlé tàbí oríkì tí ó tún gbajúmọ̀ fún àwọn ẹ̀dá tí kì í ṣe ènìyàn wọ̀nyí, pàápàá àwọn tí ó jẹ́ ẹranko, láti jẹ́ kí ìfìwàwẹ̀dá wọn túbọ̀ lọ́ọ̀rìn. Lára irú àwọn tí wọn tún máa ń ṣe àmúlò àpèlé tàbí oríkì wọn bẹ́ẹ̀ ni a kọ orúkọ wọn àti àpèlé wọn yìí:

Ìjàpá – Ìjàpátìrokò, Ọkọ Yánníbo
Ọ̀nì – Ọ̀nì wàràkà
Ẹkùn– Ògìdán olóólà ijù
Erin– Erin Lákátabú, Àjànàkú

### 4.2.2 Àpèjúwe àti Ìsínjẹ

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, a kì í dárúkọ àwọnàbísọ ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ tàbí kí a ṣe àpèjúwe tí ó lóòrìn nípa wọn. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé ìfìwàwẹ̀dá, láti mú àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ní àwòmọ́ ènìyàn gidi láwùjọ kọ́ ni ohun tí ó ṣe pàtàkì nínú àlọ́ onítàn pípa. Irú àpèjúwe àti àlàyé nípa ẹ̀dá ìtàn tí a máa ń sábàá bá pàdé nínú àlọ́ onítàn ni "Ọkùnrin àgbẹ̀ kan ní ìyàwó méjì, ó mú èyí ìyàwó lọ sí oko ní ọjọ kan, Ìyáálé wà nílé,""Ọdẹ kan wà tí ojú ọmọ ń pọ́n púpọ̀," " Ní àkókò kan ọmọdékùnrin kan wà tí kò ní bàbá àti ìyá tàbí olùtọ́jú kankan" "(Àpáta Akò mọ ọdún ìgbéjáde: 6, 11, 25)."Bàbá àgbẹ̀ kan wà,""Tọkọtìyàwó kan wà.Wọ́n bí ọmọ mẹ́tà,""Ọmọbìnrin arẹwà kan wà," (Ọ̀páọ̀tun, 1994: 36, 41, 51.) Kò sí àní àní pé àwọn irú àlàyé àti àpèjúwe yìí kò kún tó, pàápàá fúnìfìwàwẹ̀dá olú ẹ̀dá ìtàn tàbí àwọn ẹ̀dá ìtàn pàtàkì míràn. Nínúàwọn àlọ́ olólórogún ṣàṣà ni èyí tí a ti máa ń dárúkọ àbísọìyàálé àti ìyàwó, tí wọ́n jẹ́ ẹ̀dá ìtàn pàtàkì ju lọ inú ìtàn àwọn àlọ́ náà. Orúkọ ipò wọn nínú ilé ọkọ wọn nìkan ni ohun pàtàkì tí a fi ṣe ìdámọ̀ àti ìpàálà wọn bí àpẹẹrẹ tí a ṣe tán nílsinyí. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé ìṣe àti ìwà àwọn ẹ̀dá ìtàn náà, tí wọ́n fi ń gbé ìṣẹ̀lẹ̀ inú àhunpọ̀ ìtàn kalẹ̀láti inú èyí tí wọn ó ti fa ẹ̀kọ́ tí wọ́n fẹ́ kọ́ àwọn ọmọ yọ ni ohun tí óṣe pàtàkì ju ìfìwàwẹ̀dá tàbí mímú ẹ̀dá ìtàn ní àfijọ ènìyàn lójú ayé nítòótọ́. Ohun kan tí ó tún fi hàn wí pé ìfìwàwẹ̀dá gẹ́gẹ́ bí àbùdá ajẹmọ́nà ìgbétànkalẹ̀ kò lóòrìn dàbí alárà nínú àlọ́ onítàn ni pé ìhà kan ṣoṣo ni àwọn ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ onítàn máa ń ní gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ti ṣe ṣaájú.

O yẹ kí á mẹnu bà á pé nínú àlọ́ onítàn pípa,àpàlọ́ lèfi yíyí ohùn ara rẹ̀ padà tàbí fìmúlò ẹ̀yà ara rẹ̀ mìíràn ṣe ìgbékalẹ̀ ìsínjẹ ẹ̀dá ìtàn ní ọ̀nà tí àwọn ọmọdé tí wọ́n jẹ́ agbálọ̀ọ́ yóò fi ní òye kíkún tí wọ́n fẹ́ kí wọ́n ní nípa irú ẹ̀dá ìtàn náà tàbí ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ sí i. Ólè fi imú sọ̀rọ̀ láti fi hàn pé aránmú ni Ìjàpá, bí àpẹẹrẹ.Nítorí kò ní iho imú tí ó tobí ni wọ́n ṣe fi irú ìfìwàwẹ̀dá bẹ́ẹ̀ wọ̀ ọ́ bí aránmú. Àpàlọ́ lè fi ọwọ́ rẹ̀ méjèèjì ṣe àpèjúwe títobi Erin tàbí kí ó ṣe òhùn gẹ̀dẹ̀gbẹ̀ láti fi bíbú ìbínú kìnnìhún hàn bí ó ṣe ń pa àlọ́ rẹ̀ lọ. Àǹfàní wíwà papọ̀, tí apàlọ́ àti agbálọ̀ọ́ wà papọ̀, ní ojú agbo àlọ́ pípa ni èyí fi ṣe é ṣe; wọ́n ní àǹfàní rírí ara wọn ní ojúkorojú. Bí a bá ti da àlọ́ náà kọ sínú ìwé, èyí kì í sí níbẹ̀ mọ́.

### 4.3 Ìlò Èdè

Àlọ́ onítàn ní bátàní ìlò èdè tó mú un yàtọ̀ sí àwọn ìtàn àròsọ alohùn Yorùbá yòókù. Àwọn bátànì ìlò èdè kan wà nínú àlọ́ onítàn tó jẹ́ pé wọn kì í jẹyọ nínú lítíréṣọ alohùn Yorùbá kankan ju inú àlọ́ onítàn lọ. Àpẹẹrẹ ni àwọn ìpèdè ìṣídé àlọ́ onítàn, ìpèdè ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn,ti ìpari ìtànàtitìkádìí àlọ́ onítàn nílẹ̀. Gbogboàwọn eléyìí ni a ti ṣe àlàyé ṣaájú ní ìpín kìn-ín-ní Módù yìí. [Tún wo apá kìn-ín-ní módù kejì náà.] Nítorí náà a kò ní í gbara wa lákòókò mọ́ lórí àwọn ìpèdè náà ní ibíyìí mọ́. Ohun kan tí mo gbà ọ́ níyànjú láti ṣe ni wí pé kí o wá oríṣiríṣi àwọn àpẹẹrẹ ìpèdè náà,

yàtọ̀ sí àwọn èyí tí a ti gbé yẹ̀wò wọ̀nyẹn. Wo inú Babalọlá (1973 àti 1979) pẹ̀lú Ọ̀pádọ̀tun (1984) fún oríṣiríṣi ẹ̀dà àwọn ìpèdè náà. O sì tún lè ṣe ìwádìí ni àwùjọ agbègbè rẹ. Àbùdá àwọn gbólóhùn tí apàlọ́ fi máa ń ṣe àgbékalẹ̀ ààrín àhunpọ̀ ìtàn àlọ́ ni a óò gbájú mọ́ báyìí.

## 4. 3.1 Àbùdá àwọn gbólóhùn ààrín àhunpọ̀ ìtàn

Gbólóhùn abọ́dé,ìyẹn ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ ìṣe, ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn gbólóhùn inú ààrín àhunpọ̀ àlọ́ sábà máa ń jẹ́. Wọn kì í gùn. Ohun tí ó jẹ́ kí èyí rí bẹ́ẹ̀ ni pé àwọn ọmọdé ni olùgbọ́ àlọ́. Bí gbólóhùn inú àlọ́ onítàn bá gùn jù, òye ọ̀rọ̀ tí à ń sọ le má tètè yé ọmọdé tí ó jẹ́ olùgbọ́. Bí èyí bá wáyé, àfojúsùn àwùjọ nínú àmúlò àlọ́ onítàn kò le so èso rere. Iṣẹ́ àlàyé tàbí ìròyìn ní àwọn àpalọ́ máa ń fi gbólóhùn wọ̀nyí jẹ́. Àwítúnwí onítumọ̀ a sì tún máa wáyé nínú àlọ́ pípa fún ìtẹnumọ́, kí àwọn ọmọdé le ní òye ohun tí apàlọ́ ń sọ ní kíkún. Àwọn apàlọ́ máa ń ṣe ìmúlò àwọn oríṣiríṣi gbólóhùn aláàyé tàbí oníròyìn.Àpẹẹrẹ àwọn atọ́ka irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ ni, "Báyìí ni...," "Bí ó ti...," "Nígbà tí...," "Ńṣe ni...," "Bí...ṣe...," "Ṣàdédé ni...," "Lójú ẹsẹ̀ ni...," "Lẹ́yìn náà ni ...," "Ibi tí...ti...," "Àfi bí...," Ṣùgbọ́n nígbà tí...," "Ṣùgbọ́n ṣá...," "Ní kúkurú ...," 'Láì fa ọ̀rọ̀ gùn ...," "Kí á má bá Òpó lọ ilé Olóròó ...," àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

A lè rí orin inú àlọ́ náà gẹ́gẹ́ bí oríṣi bátànì ìlò èdè kan, lááyè tirẹ̀,tí a fi ìwọ́hùn àti ìwéhùn dídùn gbé kalẹ̀ ní àyèaratirẹ̀. A rí i gẹ́gẹ́ bí ìmúlò ewì nínú ìgbékalẹ̀ ìtàn sísọ. A ti ṣe àlàyé lórí orin àlọ́ bí ewì ọmọdé, asì ti wò ó gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú àwọn àbùdá àhunpọ̀ ìtàn. Ohun tí a kàn tún fẹ́ pe àkíyèsí sí ní ìsinsìnyí ni bátànì ìgbékalẹ̀ ìhun àwọn orin àlọ́ lápapọ̀ àti irú bátànì gbólóhùn àti ẹyọ ọ̀rọ̀ inú wọn. A ti sọ tẹ́lẹ̀ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ orin àlọ́ ní ó máa ń jẹ́ oníbátànì lílé àti gbígbè. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà apàlọ́ kọ́kọ́ máa ń fi ègbè orin bẹ̀rẹ̀ láti kọ́ àwọn ọmọ ní bí wọn yóò ṣe máa gbè é.Ó lè gbé e kalẹ̀ báyìí:

Apàlọ́: Ẹ́ ẹ́ máa sọ pé Kín-in-rín-jingbin
Agbálọ̀ọ́: Kín-ìn-rín-jingbin
Apàlọ́: Kínrin kínrin-jingbin
Agbálọ̀ọ́: Kín-ìn-rín-jingbin

Lẹ́yìn náà ni yóò wá máa fi àwọn gbólóhùn abọ́dé, lé orin náà síwájú sí i, láti ṣàgbékalẹ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn náà, tí àwọn ọmọ tí wọ́n jẹ́ agbálọ̀ọ́ yóò sì máa fi ìpèdè tí apàlọ́ kọ́ wọn gbè é nìṣó. Ìtẹ̀síwájú orin àlọ́ tí a ṣe àpẹrẹ ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀ ni èyí, bí àpẹẹrẹ:

Apàlọ́: Oníkàn yí rọra
Agbálọ̀ọ́: Kín-ìn-rín-jingbin
Apàlọ́: Tèmi ṣe lè dèpè
Agbálọ̀ọ́: Kín-ìn-rín-jingbin
Apàlọ́: Ìwọ́ ká, èmí ká

Agbálọ̀ọ́: Kín-ìn-rín-jingbin
Apàlọ́: Èpè kan ò pahun
Agbálọ̀ọ́: Kín-ìn-rín-jingbin

Nínú àwọn orin àlọ́ mìíràn, gbólóhùn tí apàlọ́ yóò kọ́kọ́ lé le ju ẹyọ kan lọ. Yóò kọ́kọ́ ṣe àdákọ orin kí ó tó wáyí i sí bátànì onílílé àti gbígbè. Àwọn olùgbọ́ yóò sì máa fi gbólóhùn tàbí ìpèdè ìgbẹ̀yìn èlé orin yìí gbè é bí ó ti ń lé orin náà nìṣọ̀ó. Bí àpẹẹrẹ:

Apàlọ́: Ẹ ṣáà jẹ́ ó pa mí
Ẹ ṣáà jẹ́ ó pa mi
Èmi Òtoǹtobẹ́lẹ́jẹ́
Èmi Òtoǹtobẹ̀lẹ̀jẹ̀
Èmi tí mó mórí jọká
Tí mo mọ́rùn jejò
Tí mo mú gbogbo ara pọ́n wẹ̀ẹ̀rẹ̀rẹ̀
Ońdè mẹ́jìdílógún
Lońdè ọkọ mi
Ọ̀kan ń jákéré-korò
Ayẹyẹ ilẹ̀kẹ̀
Agbálọ̀ọ́: Ayẹyẹ ilẹ̀kẹ̀
Apàlọ́: Akérékorò
Agbálọ̀ọ́: Ayẹyẹ ìlẹ̀kẹ̀ ....

Nígbà míràn, ègbè tí a ó fi gbe orin àlọ́ ọlọ́pọ̀ gbólóhùn èlé báyìí le jẹ́ ìpèdè tí kò sí lára àwọn gbólóhùn tí apàlọ́ lé náà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìpèdè ègbè orin àlọ́ ní í máa sábàá jẹ́ ọ̀rọ̀ idíófóònù (afiró-gbóyeyọ) bí i "Jáńkálátófé," "Àlùjan-n-jan-kíjàn", "Téré nànà jala-ń-kato," "Alugbin-in-rin," "Ẹ̀rẹ̀kúẹwẹlẹ" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A kì í sì í sábàá fiyè síìtumọ̀ wọn.Iṣẹ́ kan tí ó dájú pé àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ń jẹ́ nínú orin àlọ́ ni mímú orin ládùn. [wá oríṣiríṣi àpẹẹrẹ sí i fúnra rẹ.]

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ohun tí a jíròrò lé lorí nínú orí yìí ni ẹ̀dá ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ìlò èdè nínú àlọ́ onítàn.

- Ọ̀nà méjì tí a pín àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ sí ni ẹlẹ́mìí àti aláìlẹ́mìí.
- Àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ẹlẹ́mìí ni àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ajẹméniyàn, ajẹmẹ́bọra àti ajẹmẹ́ranko.
- Àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ aláìlẹ́mìí ni àwọn ẹ̀dá ìtàn ajẹméwéko, ajẹmókùúta, àwọn ohun àfojúrí/àrídìmú mìíràn àti àwọn ẹ̀dá ìtàn àìfojúrí tàbíafòyemọ̀.
- A sọ̀rọ̀ nípa ìfìwàwẹ̀dá. A ṣàlàyé pé a máa ń lo orúkọ ẹ̀dá ìtàn, ìrísí, ìṣesí àti ìhùwàsí láti fi dásọ ìwà wọ ẹ̀dá ìtàn àlọ́ níwọ̀nba.

- A ṣàlàyé ìdí tí ìfìwàwẹ̀dá kò fi jẹ àwọn apàlọ́ Yorùbá lógun tó bẹ́ẹ̀ jù bẹ́ẹ̀ lọ.
- Ìlò èdè ni a jíròrò lé lórí gbẹ̀yìn. A rán wa létí nípa àwọn ìpèdè ìṣíde àlọ́, ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn, ìparí àhunpọ̀ ìtàn àti tìkádìí àlọ́ pípa.
- A jíròrò lórí àwọn àbùdá gbólóhùn ààrín àhunpọ̀ ìtàn pẹ̀lú ti orin inú àlọ́ onítàn.

Nítorí pé a ti wo bátànì àwọn gbólóhùn ìṣíde àlọ́, ti ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn, ipárí àhunpọ̀ ìtàn àti ìkádìí àlọ́ pípa tẹ́lẹ̀ ni a kò fi tún ṣe àtúnwí wọn mọ́ ní ibí; ara ìmúlò èdè náà ni wọ́n jẹ́.Nítorí náà kí o lọ tún wọn kà ní apá kìn-ín-ní módù kejì àti apá kìn-ní-módù kẹta fún ìránnilétí àti gẹ́gẹ́ bí ara ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

A ti túbọ̀ fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ayé inú àlọ́ kò bá ti ojú ayé láwùjọ ọmọ ènìyàn mu rẹ́gírẹ́gí. Nípasẹ̀ àgbéyẹ̀wò oríṣiríṣi ẹ̀dá ìtàn inú àlọ́ àti ìfìwàwẹ̀dá wọn ni a ṣe fi eléyìí hàn gbangba nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Àjọṣe a máa wáyé láàrin gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn tí wọ́n jẹ́ ènìyàn àti àwọn tí kì í ṣe ènìyàn ní ayé àlọ́. Kò sí àní àní pé ayé mérìíyìírí ni irú ayé bẹ́ẹ̀. Nípa gbígbé ìwà wọ àwọn ẹ̀dá tí kì í ṣe ènìyàn wọ̀nyí ni àwọn apàlọ́ Yorùbá fi ṣe àṣeyọrí náà. Àbùdá ènìyàn kan tí gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn náà ní ni pé wọ́n lè sọ̀rọ̀ bí ènìyàn.Èyí kò lè ṣẹlẹ̀ bẹ́ẹ̀ lójú ayé. Ohun kan tí a kò gbọdọ̀ gbàgbé ni pé àrokò nípa ẹ̀dá ènìyàn láwùjọ ni wọ́n fi gbogbo àwọn ẹ̀dá ìtàn náà pa.

Àmúlò ọnà ìfìwàwẹ̀dá nínú àlọ́ onítàn kò lóòrìn tó nǹkan nítorí kì í ṣe ìṣewẹ́kú pẹ̀lú ojú ayé ni ó jẹ àwọn apàlọ́Yorùbá lógún, bí kò ṣe ẹ̀kọ́ tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àlọ́ náà kọ́ni. Kì í ṣe pé àmúlò orúkọ àti àpèjúwe pẹ̀lú àlàyé ṣíṣe kò sí rárá bí àlàyé wa ti fi hàn. Kò kàn lọ́ọ̀rìn ni. Kò yà wá lẹ́nu pé gbólóhùn abọ́dé ni ó wọ́pọ̀ nínú àlọ́ pípa. Èyí ni kò ní í jẹ́ kí ìtàn náà dàrú mọ àwọn ogo wẹẹrẹ náà lójú tí òye ẹ̀kọ́ inú rẹ̀ yóò sì fi yé wọn yékéyéké.Síbẹ̀ síbẹ̀, ó yẹ kí á tọ́ka sí i pé kì í ṣe ẹ̀kọ́ nípa ìwààti ìṣe ènìyàn láwùjọ, àyíká àti ojú àmúwayé pẹ̀lú àṣà àwùjọ nìkan ni àwọn ọmọ ń kọ́ ní àkókò àlọ́ pípa, wọ́n tún ń kọ́ nípa àmúlò èdè náà pàápàá.Ìdí nìyí tí ìmúlò àwọn èdè inú àlọ́ pàápàá ti inú àwọn orin, tí àwọn ọmọ máa ń gbádùn, tí wọn sì máa ń kópa nínú rẹ̀ fi gbọ́dọ̀ dùn dáadáa.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ ẹlẹ́mìí nínú àlọ́ onítàn Yorùbá.
2. Jíròrò lórí oríṣiríṣi orúkọ mẹ́rin tí àwọn apàlọ́ máa ń mú lò nínú ìfìwàwẹ̀dá àwọn ẹ̀dá ìtàn àlọ́ onítàn Yorùbá?
3. Ǹjẹ́ lóòtọ́ ni pé ọ̀rọ̀ gbogbo kì í sé lórí alábahun? Dá sí ọ̀rọ̀ yí.
4. Ṣe àlàyé lórí bátànì àmúlò èdè ìbẹ̀rẹ̀, ààrín àti ìparí àhunpọ̀ ìtàn inú àlọ́ onítàn Yorùbá àti pàtàkì wọn?
5. Kín ni àríwísí rẹ nípa àwọn ìpèdè ìṣíde àti ìkádìí àlọ́? Ǹjẹ́ wọn tilẹ̀ ní ìwúlò kan dàbí alárà?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adégòkè, L.A. 2006. *Folktales*. Sulek-Temik Publishing Company,Ìkìrun.

Bámgbóṣe, A. 1969 Yorùbá Folktales, *Ìbàdàn*, 6 -12; Àtúntẹ̀jáde nínú Lawal, N. S., Sadiku, N. O. S àti Dọ̀pámú A. 2000*Understanding Yorùbá Life and Culture*; 547 – 561, New Jersy.

Àmọ̀rí, A. 1978. *Ìdí Abájọ Kìnnìún*. Manmillan Nigeria Publishers Ltd.,Lagos. Apata, F.O. Akò mọ ọdún ìgbéjáde, *Àwọn Ìtàn Aládùn*. Ministry of Education, Ìbàdàn.

Babalọlá, A. 1973. *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá: Apá Kìíní*. University Press Limited,Ìbàdàn.

Babalọlá, A. 1979. *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá: Apá Kejì* University Press Limited,Ìbàdàn. Fuja, A. 1967.*Four Hundred Cowries: Traditional Stories of the Yorùbá*, Oxford University Press, Ìbàdàn.

Ògúndèjì, P.A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. University ofÌbàdàn Centre forExternal Studies.Ìbàdàn.

Òjó, O. *Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yánníbo*, Longman Nig Ltd., Lagos

Ọnàsànyà, O. 1973. *Àṣàyàn ìtàn Ọmọ Obòkun*, Macmillan Nigeria Publishers Ltd.,Lagos.

Ọ̀pádọ̀tun, Ọ. 1994. *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Y-Books,Ìbàdàn.

# ÌPÍN 4 ERÉ ONÍṢE I: ỌDÚN ÌBÍLẸ̀

## ÀKÓÓNÚ


1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  4.1 Ọ̀rọ̀ Díẹ̀ Nípa Àríyànjiyàn Lórí Pípe Ọdún Ìbílẹ̀ níEré Oníṣe.
  4.2 Awọn Àbùdá Eré Oníṣe Lápapọ̀
  4.3 Àbùdá Eré Oníṣe Nínú Ọdún Ìbílẹ̀ Yorùbá
    4.3.1 Aṣèsínjẹ àti Ẹ̀dá Ìtàn
    4.3.2 Ibi Ìṣeré, Ibùdó Ìtàn àti Òǹwòran
    4.3.3 Aṣọ Eré, Ìbòjú, Ohun Èlò Ìṣeré; ti Ìléwọ́ àti ti Ìtàgé
    4.3.4 Àhunpọ̀ Ìtànàti Ìṣẹ̀lẹ̀ inú Eré
    4.3.5 Ìsọ̀rọ̀ǹfèsì, Orin, Ìlù àti Ijó
    4.3.6 Ìwúlò
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìhín ohun tí ó jẹ wá lógún jù lọ ni láti fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé a lè fi ojúeré oníṣe wo àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá. A óò ṣe èyí nípa ṣíṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá àjẹmọ́nà àti ti ajẹmọ́ ìmúlò rẹ̀. Ohun méjì tí a óò kọ́kọ́ ṣe ni pé a óò sọ̀rọ̀ níwọ̀nba lórí àríyànjiyàn nípa bóyá eré oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀ tàbí bẹ́l kọ́. A óò sì jíròrò nípa àbùdá eré oníṣe bí àwọn aláwọ̀ funfun ṣe là á kalẹ̀ kí a lè rí ibí ìjọra àti ìyàtọ̀ àárín àwọn irúfẹ́ eré oníṣe tiwọn àti ti àbáláyé tiwa. Ohun kan tí a tún ní láti mẹ́nu bà nipé a kò ní fúnka mọ ọ̀rọ̀ ìhà méjì tí eré oníṣe pín sí gẹ́gẹ́ bí i lítíreṣọ̀ tàbí eré onítàn àti gẹ́gẹ́ bíìṣeré tàbí tíátà. Méjèèjì ni a ó kó papọ̀ nítorí wọ́n yí wọ inú ara wọn nínú eré oníṣe àbáláyé Yorùbá tí a fẹ́ gbé yẹ̀ wò.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó ó ti lè ṣe àlàyé lórí ìdí tí a fi lè pe ọdún ìbílẹ̀ ní eré oníṣe láàyè ara tirẹ̀. Oóti lè sọ nípa àwọn àbùdáeré oníṣe lápapọ̀. O ó sì lè ṣe àlàyé ìjẹyọ wọn nínú ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá, kí ó sì sọ ìwúlò àwọnọdún ìbílẹ̀ náà. Nípa bẹ́ẹ̀, o ó lè fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé eré oníṣe jẹ́ ọdún ìbílẹ̀ láàyè ara tirẹ̀.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Dárúkọ àwọn àbùdá eré oníṣe mẹ́rin tí o mọ̀.
2. Dárúkọ Ọdún ìbílẹ̀ Yórùbá mẹ́ta tí o mọ̀. Kín ni ìwúlò wọn láwùjọ tí wọ́n ti ń ṣe wọ́n?
3. Kín ni ìyàtọ̀ láàrin eégún aláré àti àwọn eégún mìíràn?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ọ̀rọ̀ Díẹ̀ Nípa Àríyànjiyàn LóríPípe Ọdún Ìbílẹ̀ ní Eré Oníṣe

Àríyànjiyàn wà láàrin àwọn onímọ̀ lórí pípe ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá àti ti ilẹ̀ afíríkà lápapọ̀ ní eré oníṣe. Àwọn kan fara mọ́ ọn wí pé a lè fi ojú eré oníṣe wo ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Áfíríkà, àwọn kan sì kọ̀ jálẹ̀ pé bẹ́ẹ̀ kọ́. Ohun tí àwáṣe àkíyèsí pé ó fa àríyànjiyàn yí ni wí pé àwọn tí kò gbà pé ọdún ìbílẹ̀ jẹ́ eré oníṣe ń lo àwọn àbùdá eré oníṣe ní ilẹ̀ Yúróòpùnìkan gẹ́gẹ́ bí odiwọ̀n ohun tí eré oníṣe gbọ́dọ̀ jẹ́. Àkíyèsí nípa àṣà káàkiri àgbáyé ni pé àṣà kì í rí bákan náà ni ibi gbogbo jákèjádò àgbáyé. Bí àpẹẹrẹ, kò sí ibi tí wọn kì í ti í gbéyàwó, tí wọn kì í ti í bímọ, kí wọ́n sì tọ́jú ìyálómọ àti ọmọ rẹ̀ tuntun. Kò sí ibi tí wọn kì í ti í dáná oúnjẹ kí wọ́n sì jẹun. Kò sì sí ibi tí wọn kì í ti í wọṣọ sára tàbí kí wọ́n bo ìhòòhò wọn. Ṣùgbọ́n ìlànà tàbí àṣà bí a ṣe ń ṣe gbogbo nǹkan wọ̀nyí yàtọ̀ọ̀tọ̀ láti agbègbè dé agbègbè àti láti ẹ̀yà kan sí ẹ̀yà míràn. Oríṣiríṣi sì ni àwọn ohun tí ó máa ń fa sábàbí ìyàtọ̀ náà. Ó lè jẹ́ bí ojú ọjọ́ ti rí ní agbègbè kọ̀ọ̀kan tàbí irú àwọn ohun tí ẹlẹ́dàá fi ṣíkẹ́ wọn ni agbègbè ibẹ̀. Pabanbarì rẹ̀ sì ni ìrírí àwọn babańlá wọn láti ọjọ́ pípẹ́. Bí àwọn ará ìṣáájú bá ṣe fi lé wọn lọ́wọ́ náà ni wọn yóò máa ṣe é. Bí a bá rí eré oníṣe gẹ́gẹ́ bí àṣà kan, ajẹ́ pé kò lè yàtọ̀ sí àwọn àṣà ìyókù. Ní pàtó ohun tí à ńsọ ni pé, kò pọn dandan kí eré oníṣe ní ilẹ̀ Áfíríkà ó bá eré oníṣe ní ilẹ̀ Yúróòpù mu rẹ́gírẹ́gí. Ṣùgbọ́n láìsí àní àní wọn yóò jọra dé ààyè kan bí àwọn méjèèjì bá jẹ́ eré oníṣe ní òtítọ́. Ajẹ́ pé oríṣi tàbí ká sọ pé ẹ̀yà ohun kan náà ni wọ́n jẹ́ nìyẹn.

Ojú àmúwoṣẹ́ ọnà ní ilẹ̀ Áfíríkà ní ààrọ̀ ọjọ́ yàtọ̀ sí ti ilẹ̀ Yúróòpù. A kì í sabàá ya iṣẹ́ ọnà àbáláyé kúrò nínú iṣẹ́ tí a ńfi iṣẹ́ ọnà náà jẹ́ tàbí ìwúlò rẹ̀. Púpọ̀ nínú àwọn ohun èlò ilé bí àpótí ìjokòó, tàbí igbá tí wọn fi ń gbé obì fún àlejò, òpó ilé àti ilẹ̀kùn, pàápàá èyí tí wọ́n ń pè ní ààsẹ̀ ni àwọn agbẹ́giléré máa ń ṣe ọnà sí lára bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n wọn ń lò wọ́n fún ohun kan tàbí òmíràn. Bákan náà ni ó jẹ́ pé gbogbo àwọn ère òrìṣà Yorùbá bí ere Èṣù, ti Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tàbí Eégún ni ó jẹ́ pé iṣẹ́ ọwọ́ àwọn agbẹ́gilére; iṣẹ́ ọnà, ni wọ́n kọ́kọ́ jẹ́ kí, wọ́n to di àmúlò nínú ẹ̀sìn. Ohun tí à ń sọ ni pé a kò lè ṣọ pé àwọn ohun èlò àti òpó ilé, ààsẹ̀ àti ere òrìṣà kì í wá ṣé iṣẹ́ ọnà mọ́ rárá rárá nítorí ìmúlò wọn yẹn. Bákan náà ni ọ̀rọ̀ rí nínú iṣẹ́ ọnà ohùn, torí pé a ti ń fi oríkì ki èniyàn kan tàbí òrìṣà kan, tàbí tí à ń ṣe ìmúlò ọfọ̀ láti pa oró ejò bí àpẹẹrẹ, kò sọ pé wọn kì í ṣe ewì mọ́. Ọnà àti ètò inú wọn fi wọ́n hàn gédégédébí ewì. Bákan náà sì ni ọ̀rọ̀ rí

nípa eré oníṣe. Tí a bá ti rí àwọn àbùdá tí ó fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ bí eré oníṣe, bí kò tilẹ̀ ṣe rẹ́gí pẹ̀lú ti òkè òkun, tórí pé à ń lò ó nídìí ẹ̀sìn kò sọ pé kì í ṣe ọnà eré oníṣe mọ́ (wo Ògúndèjì 2000 àti 2005 fún àlàyé síwájú sí i).

Lára ohun tí ó máa ń jẹ́ àwíjàre àwọn alátakò èrò náà ni pé àwọn ẹlẹ́sìn ìbílẹ̀ ilẹ̀ Áfíríkà, tí a pè ní òṣèré nínú ọdún ìbílẹ̀, kò rí ara wọn gẹ́gẹ́ bí òṣèré, ẹlẹ́sìn òrìṣà ni wọ́n ka ara wọn sí(Beier 1967). Ṣùgbọ́n kò di ìgbà tí àwọn akópa nínú ẹ̀sìn ìbílẹ̀ bá tó ó sọ wí pé àwọn ń ṣe àmúlò ọnà ìṣeré kí onímọ̀ tó ṣe ìdámọ̀ irú ọnà tí ó bá jẹyọ níbẹ̀.Ohun tí ó bá mú kí a gba ìjálá eré Ògún, ẹ̀ṣà egúngun, Ṣàngó pípè, ọfọ̀ abbl. gẹ́gẹ́ bí ewì náà ni yóò mú wa gba ọdún ìbílẹ̀ bí eré oníṣe. Kò sí bí ọ̀bọ ti ṣe orí, tí ìnàkí kò ṣe ni ọ̀rọ̀ náà. Àgbéyẹ̀wò kíkún lórí àríyànjiyàn yí dí inú kọ́ọ̀sì míràn ní ọjọ́ iwájú. Ẹ jẹ́ kí a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá eré oníṣe bí àwọn àláwọ̀ ará Yúróòpù ti là á sílẹ̀ ná, kí a tó wa lọ wo bí wọn ṣe jẹ yọ nínú ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá àti àwọn àbùdá mìíràn tí ó bá yà á sọ́tọ̀.

### 4.2.0 ÀwọnÀbùdá Eré Oníṣe Lápapọ̀

Pàtàkì nínú àwọn àbùdá eré oníṣe jákè jádò àgbáyé ni ìsínjẹ, ṣùgbọ́n ohun kán tí óyẹ ní mímọ̀ ni pé kì í ṣe eré oníṣe nìkan ni ìsínjẹ jẹ́ àbùdá ìpìlẹ̀ fún. Bákan náà ni ójẹ́ fún gbogbo àwọn iṣẹ́ ọnà yókù. Lórí ìsínjẹ ni gbogbo àwọn àbùdá eré oníṣe yòókù dúró lé. Láti kẹ́sẹjárí nínú ṣíṣe ìsínjẹ ẹ̀dá ìtàn àtiìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn ni àwọn òṣèré (tí wọ́n jẹ́ àṣesínjẹ) ṣe máa ń ṣàmúlò gbogbo èròjà àti ọgbọ́n ìṣeré ní ibi ìṣeré (ìtàgé tàbí ojú agbo eré), fún ìgbádùn àwọn òǹwòrán. Yàtọ̀ sí òṣèré,ẹ̀dá ìtàn,ibi ìṣeréàti òǹwòran tí a ti mẹ́nu bà, àwọn àbùdá mìíràn tí wọ́n máa ń ṣàmúlò gẹ́gẹ́ bí ọgbọ́n ìṣèsínjẹ náà niaṣọ eré, ìbòjú, ìfọwọ́ àti ẹ̀yà ara yòókù júwe ọ̀rọ̀, ìrìn sókè sódò,ohun èlò ìléwọ̀ àti ti ibi ìṣeré pẹ̀lú orin, ìlù àti ijó, kókó ọ̀rọ̀,ibùdó ìtàn, àhunpọ̀ ìtàn àti ìsọ̀rọ̀-ǹ-gbèsì. Àwọn àbùdá eré oníṣe méjì tí ó gbẹ̀yìn yìí ni àwọn àwọn ará Yúróòpù kà sí kò-ṣe-é-má-nìí jù lọfún eré oníṣe gẹ́gẹ́ bí lítíréṣọ̀ ní ti wọn.

### 4.3 Àbùdá Eré Oníṣe Nínú Ọdún Ìbílẹ̀

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ, àwọn àbùdá eré oníṣe kan máa ń jẹyọ nínú ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá, èyí tí ó tó, gẹ́gẹ́ bí ẹ̀rí, láti mú kí pe àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà ní eré oníṣe lááyè ara wọn. Bí a bá sọ pé eré oníṣe ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá, ohun tó mú wa sọ èyí ni pé ìhun ìgbékalẹ̀ àti àbùdá àwọn ọdún ìbílẹ̀a máa ní àfijọ eré oníṣe bí a ṣe mọ̀ ọ́n ní òde òní. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ, kò di ìgbà tí àwọn akópa nínú ọdún ìbílẹ̀ bá tó rí ara wọn bí òṣèré kí àwọn onímọ̀ tó lè sọ pé irúfẹ́ eré oníṣe kan ni ohun tí wọ́n ń ṣe jẹ́. Bí ó ṣe jẹ́ pé kò dìgbà tí apọfọ̀ bá tó sọ pé ewí ni òhun ń ké kí àwọn onímọ̀ ìṣọwọ́lò-èdè tó mọ̀ pé ewì ni apọfọ̀ ń ké, torí ààtò ọ̀rọ̀ àti bátànì ìṣọwọ́lò-èdè ajẹméwì tí ó kún inú ọfọ̀ fọ́fọ́. Àwọn àbùdá eré oníṣe tí ó sodo sínú ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá àti ti ilẹ̀ Áfíríkà lápapọ̀ tó ohun tí a fi lè rí wọn gẹ́gẹ́ bí irúfẹ́ eré oníṣe lááyè ara tiwọn.Àwọn àbùdá eré oníṣe náà, bí wọ́n ti jẹyọ

nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá ni a jíròrò lé lórí nísàlẹ̀.(o tún lè wo Ògúndèjì 2000 àti 2005 fún àlàyé síwájú sí i)

### 4.3.1 Aṣèsínjẹ àti Ẹ̀dá Ìtàn

Ìsínjẹ ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ eré oníṣe gẹ́gẹ́ bí ati sọ ṣaájú. Ẹni tí ó ń ṣe ìsínjẹ ẹ̀dá ìtàn ni aṣèsínjẹ nínú iṣeré oníṣe. Òun náà ni a tún mọ̀ sí òṣèré. Ìsínjẹ ni kí ènìyàn ó máa ṣe gẹ́lẹ́ bí ẹnìkan ti ṣe. Tí a bá ṣe ẹ̀dà ohun kan tí ẹ̀dà náà fi ní àfijọ ojúlówó ohun tí a ṣẹ̀dà rẹ̀, ìsínjẹ ti wáyé nìyẹn. Kì í ṣe ènìyàn nìkan ni a lè sín jẹ, ṣùgbọ́n nínú eré oníṣe ènìyàn ni aṣèsínjẹ máa ń sín jẹ lọ́pọ̀ ìgbà. Nínú iṣẹ́ àwọn oníṣẹ́ ọnà míràn, ó lè jẹ́ igi,amọ̀, tàbí ohun èlò míràn ni wọnfi ń ṣe ìsínjẹ yálà ènìyàn tàbí ohun mìíràn. Ẹ̀dá ìtàn ni a máa ńpe ẹni tí aṣèsíjẹ ń síjẹ nínú ìṣeré oníṣe.Ẹ̀dá ìtàn ìtàn ìwáṣẹ̀ tàbí ti ìtàn àkọnikàyéfì ni aṣèsínjẹ má ń sínjẹ nínú ìṣeré ọdún ìbílẹ̀.Aṣèsínjẹ ni ó máa ń yá ẹ̀dá ìtàn ní àgọ́ ara tirẹ̀ ní àkókò ìṣeré. Nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀, irú ẹdá ìtàn bẹ́ẹ̀ le jẹ́ òrìṣà, baba ńlá tàbí ìyá ńlá kan, ẹranko,ẹbọra tàbí ẹ̀mí àìrí mìíràn. Àwọn ẹlẹ́gùn, abọrẹ̀ tàbí àwòrò, ọba, ìjòyè àti àwọn olùsìn tàbí ọmọ awo òrìṣà kan tàbí òmíràn, tí ó ní ipa kantàbí òmíràn láti kó nínú ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ òrìṣà tí wọ́n bá ń ṣe, ni wọ́n máa ń jẹ́ aṣèsínjẹ àwọn ẹ̀dá ìtàn ìwáṣẹ̀ tàbí takọnikàyéfì ní àkókò ìṣeré orò ọdún ìbílẹ̀. Lọ́nà míràn àwọn ni òṣèré tí ó ń ṣe ìfihàn àwọn ẹ̀dá ìtàn ìwáṣẹ̀ tàbí takọnikàyéfì ní àkókó ìṣeré ọdún ìbílẹ̀.Nípa ṣíṣe ìsínjẹ ni wọ́n sì fi máa ń ṣe ìfihàn náà.

Ẹni tí ó jẹ́ élẹ́gùn òrìṣà lè máa jẹ́ Àdìò ní ojú ayé, ṣùgbọ́n ní àkókò ìṣeré tí ó bá ti gun ẹ̀gùn òrìṣà tán, orúkọ àti oríkì òrìṣà náà ni wọn yóò máa fi pè é tí wọn yóò sì máa fi kì í ní mẹ́sàn-án mẹ́wàá ju oríkì tirẹ̀ lọ; bí wọ́n bá tilẹ̀ lo oríkì ti ara rẹ̀ rárá, níwọ̀nba ni yóò jẹ́. Èyí wà lára ohun tí ń fi hàn pé ó ń ṣe ìsínjẹ òrìṣà tí ó gun ẹ̀gùn rẹ̀ yẹn ni.Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé nígbà tí ọba bá ń kó ipa nínú ọdún ìbílẹ̀, ó ń ṣe ìsínjẹ àwọn baba ńla rẹ̀ tí ó ti wà lórí àpèrè ọba níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ni, kì í ṣe pé ojú ara rẹ̀ nìkan ni ó ń ṣe.

Bákan náà ni ẹni tí ó wà lábẹ́ ẹ̀kú ègúgún ní àkókò ọdún egúngún ń ṣe ìsínjẹ baba ńlá tí egúngún yẹn dúró fún ni. Àwọnòwe Yorùbá kan tilẹ̀ wà tí ó fi hàn gbangba pé ìsínjẹ ni wọn fi ń ṣe ìgbékalẹ̀ egúngún; ènìyàn ni ó wà lábẹ́ ẹ̀kú. Lára irú àwọn òwe bẹ́ẹ̀ ni: “Egúngún tí yóò bá padà di ènìyàn, ìwọ̀n ni kí ó rorò mọ lábẹ́ àṣọ,”“ Bàbá mọ egúngún, ìyá mọ egúngún, ó ku ni tí yóò sọ egúngún,” “Eégún mọ ohùn alágbò, alágbò náà mọ ohùn eléégún,” “Egúngun tí yóó gbayì wálé, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ijó ni yóò ti fi dánrawò níyẹ̀wù,” “Béégún bá ń léni ká máarọ́jú, bó ti ń rẹ ará ayé, náà ló ń rẹ ará ọ̀run,”(Abímbọ̀lá, 2006). Bí a bá ronú jinlẹ̀ sí àwọn òwe wọ̀nyí a óò rí i pé wọ́n ń tọ́ka sí i lọ́nà kan tàbí òmíràn pé ènìyàn ni ó wà lábẹ́ àṣọ tí à ń pè ní eégún. Aṣèsínjẹ ni ẹni náà; ó ń ṣe ìsínjẹ ará ọ̀run ní àkókò tí ó gbé eégún yẹn ni.Ará ọ̀run tí ó ń síjẹ ni ẹ̀dá ìtàn.

### 4.3.2 Ibi Ìṣeré, Ibùdó Ìtàn àti Òǹwòran

Ibi ìṣeré ni ààyè tí a yà sọ́tọ̀, tí eré oníṣe ti máa ń wáyé. A tún lè ṣe àlàyé rẹ̀ ní ọ̀nà míràn pé ó jẹ́ ibi tí àwọn òṣèré ti máa ń ṣe ìgbékalẹ̀ eré oníṣe fún àwọnònwòran láti wò. A lè pín ibi ìṣere ọdún ìbílẹ̀ sí ọ̀nà méjì gbígbòòrò; ibi ìṣeré olójúkojú àti ti aláìjólójúkojú. Ibi ìṣeré olójúkojú, tí ó kàn wá ní pàtó nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí jẹ́ ibi tí àwọn òǹwòran àti òṣèré ti lè rí ara wọn ní ojúkojú. Orí ìtàgé nínú gbọ̀ngànìṣeré (fún ìṣeré òde ǹí) tàbí ní ojú agbo eré ní ìta gbangba ni èyí máa ńsábàá jẹ́. Àwọn òṣeré àti òǹwòran kì í rí ara wọn ní ojú-kojú níbi ìṣeré aláìjólójúkojú. Bí àpẹẹrẹ òǹwòran lè gbọ́ ohùn òṣeré níbi ìṣeré orí rédíò àti tí wọ́n bá lo ẹ̀rọ ìgbohùnsílẹ̀ láti ká ohùn àwọn òṣeré sínú àworẹ́kọ̀ọ̀dù, fọ́n-ọ́n-ran téèpù tàbí Síí Diì. Wọ́n tún lè wo àwòrán alèrìn àwọn òṣèré ní orí tẹlifíṣàn, fíìmù fọ́n-ọ́n-rán tàbí àwo Síí Diì onífídíò. Bẹ́ẹ̀ ni ó ṣe é ṣe kì wọ́n wo àwòrán aláìlerìn tàbí adúró-rigidinínú ìwé eré onífọtò.Ibi ìṣeré aláìjólójúkojú kò kàn wá nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí nítorí wọn kì í ṣe ibi ìṣeré ìpìlẹ̀ fún irú eré oníṣe tí à ń gbé yẹ̀wò. Ọdún ìbílẹ̀ kì í wáyé ní orí ìtàgé tàbí inú gbọ̀ngàn ìṣeré ní ayé àtijọ́ rárá rárá.Bí abá rí ìgbékalẹ̀ ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ kan ní orí ìtàgé nínú gbọ̀ngàn ìṣeré, ó yẹ kí amọ̀ pé àṣáwọ̀ ìlànà ìṣeré òde òní ni ó kó irú àṣà bẹ́ẹ̀ dé ọ̀dọ̀ wa. Ibi ìṣeré olójúkojú ni a ní lọ́kàn tí a bá ń sọ̀rọ̀ ibi ìṣeré láti ìsinsìnyìí lọ.

Àwọn ibi ìṣeré yìí ni àwọn òṣèré ti máa ń ṣe ìsínjẹ àwọn ẹ̀dá ìtàn àti ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn,tí a sì ti máa ń ṣe ìgbékalẹ̀ ìbùdó ìtàn inú eré. Ibùdó ìtàn ni àwọn ààyè,ibi tàbí àyíká ní àwùjọ tí ó wà nínú àhunpọ̀ ìtàn; wọn kì í ṣe àwùjọ ojú ayé. Ibi ìṣeré ni àwọn òṣèré máa ń lò láti ṣe àfihàn ibùdó ìtàn ní àkókò ìgbérékalẹ̀lójú ayé. Gẹ́gẹ́ bí Oyin Ògúnbà(2000)ti wí, àwọn ibi ìyàsọtọ̀ tí ó pè ní "...ibi tí ilẹ̀ ti ní ojú" (ibi ọ̀wọ̀) ni ibi ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ máa ń jẹ́, pàápàá ní àkókò ìṣeré yẹn. Àwọn igbó ìṣorò (ì+ṣe+orò), (ó lè jẹ́ ti ìgbàlẹ̀, ti Ifá, Orò tàbí ti òrìṣà míràn), iwájúde ọba tàbí tìjòyè pàtàkì kan, iwájú tàbí àgbàlá ilé òrìṣa, ojúbọ òrìṣà, àárin ọjà, òpópónà àarin ìlú, etí odò tàbí orí odò fún àwọn òrìṣà omí, orí òkè, agbo ilé, inú ilé òrìṣà, gbàgede tàbí àgbàlá ilé òrìṣà tàbí ti ọba ìlú, ojú ọjà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí Ògúndèjì (2000) ti fi yé wa, a lè pín ibi ìṣeré inú ọdún ìbílẹ̀ sí ọ̀nà gbígbòòrò méjì. Ó lè jẹ́ ibi ìdákọ́ǹkọ̀ tàbí kọ̀lọ́fín,níbi tí ó pamọ́.Ó sì lè jẹ́ ojútáyé, ní gbangba.

Irú àwọn òǹwòran méjì tí a le tọ́ka sí nínú ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá ní àjọṣe típẹ́típẹ́ pẹ̀lú àwọn oríṣi ibi ìṣeré méjì tí a ti là kalẹ̀. Irú àwọn òǹworan náà ni àwọn awo àti àwọn ọ̀gbẹ̀rì. Àwọn awo ni àwọn ọmọ ẹgbẹ́ ìmùlẹ̀ tí ó ń ṣe gbogbo ètò ọdún ìbílẹ̀ ọrìṣà kọ̀ọ̀kan àti gbogbo ohuntí ó bá jẹ mọ́ ìsìn òrìṣà náà. Àwọn ọ̀gbẹ̀rì sì ni àwọn ará ìlú lápapọ̀ tí kò sí nínú ìmùlẹ̀ awo òrìṣà kọ̀ọ̀kan náà. Níbi ìṣeré onídàákọ́ǹkọ̀ àwọn ọmọ awo òrìṣà nìkan ni ó máa ń sábàá jẹ́ òǹwòran (àyàfi ẹni tí wọ́n bá tún gbà láàyè). Tawotọ̀gbẹ̀rì ni ó lè jẹ́ akópa gẹ́gẹ́ bí òǹwòran níbi ìṣeré olójútáyé. Àpapọ̀ àwọn òǹwòran méjèèjì yí ni òǹwòran gbogbogbòò tí

wọ́n máa ń kópa níbi ìṣeré olójútáyé. Ó yẹ kí á pe àkíyèsí sí i pé àwọn ọmọ awo tí, wọ́n ti ní ìmọ̀-ọ́n-ṣe nípa irú ìṣeré ajẹmórò òrìṣà nìkan ni wọ́n máa ń sábàá jẹ́ ojúlówó òṣeré níbi ìṣeré méjèèjì.

Gẹ́gẹ́ bí Adédèji (1969) ti fi yé wa, inú igbó ìgbàlẹ̀ àwọn eléégún ni ìṣeré orò ìgbágan tí wọn fi máa ń sẹ àìsùn ọdún egúngún ti máa ń bẹ̀rẹ̀. Orí ìkúnlẹ̀ ni wọ́n ti máa ń ṣe orò ìwúre oríṣiríṣi ní apá kìn-ín-nííṣorò yìí. Èyí sì ni ìdí tí wọn fi ń pè orò náà ní ìkúnlẹ̀ (Adédèjì, 1969). Láti alẹ́ títí di bí i ọ̀gànjọ́ òru ni àkókò tí apá kìn-ín-ní ìṣeré ajẹmórò náà máa ń wáyé nínú igbo ìgbàlẹ̀. Ní ọ̀gànjọ́ òru ni apá kejì ìṣeré ajẹmórò náà máa ń bẹ̀rẹ̀, tí wọn ó gbé Àgan la ìgboro ìlú já, títí di kò-ríni-kò-mọni.Gbígbé tí wọ́n sì máa ń gbé àgan ni wọ́n fi pe apá kejì ìṣorò náà ní ìgbágan. Bí wọ́n ti ń gbé Àgan wọ́de ní gbogbo òru náà ni wọn ó máa pe ohùn, nípasẹ̀ èyí tí gbogbòòó fi mọ̀,nínú ilé wọn, pé ọdún egúngún yóò bẹ̀rẹ̀ ní ìyálẹ̀ta.Kò sí àníaní kankan pé ibi ìṣeré onídàákọ́ńkọ́ ni igbó ìgbàlẹ̀ tí wọ́n ti ń ṣe apá kìn-ín-ní orò náà nítorí ti ó jẹ́ ibi kọ̀lọ́fin, tí ọ̀gbẹ̀rì kògbọdọ̀ dé. Ṣùgbọ́n ti àárin ìgboro tí wọ́n ti ṣe apá kejì tí ó jẹ́ ìgbÀgan gan-an-gan nílò àlàyé, kí ato lè gbà pé ibi ìṣeré onídàákọ́ńkọ́ ni. Bí wọ́n ti ń gbé Àgan yide ìlú, ohùn nìkan ni àwọn ará ìlú yóò máa gbọ́, wọn kò gbọdọ̀ fojú kan Àgan. Èyí ni pé ìséde wà. Ìsede yìí àti òru tí wọ́n ń ṣe ìyíde náà ni wọ́n fi mú ibi ìṣeré ìta gbangba náà jẹ́ tonídàákọ́ńkọ́, níwọ̀n ìgbà tí ọ̀gbẹ̀rì kò ti kópa ní ojúkojúbí òǹwòran nínú rẹ̀. Ìlú Igbó-ọrà, ní Ìbàràpá, jẹ́ àpẹẹrẹ ibi tí wọn ti máa ń gbé Àgan bẹ́ẹ̀. Àlàyé Àránsí (2016) jẹ́ kí á mọ̀ pé ibi ìṣeré onídàákọ́ńkọ́ ni àgbàlá Ọlọ́wọ̀, níÙghà Èdùmà, tí wọ́n ti máa ń ṣe orò ìṣíde ọdún Igogo. Ó fi yé wa pé “Ọlọ́wọ̀, àwọn àwòrò, àgbà ìlórò, àwọn ayaba àti ìdílé ọba...” ni wọ́n ní àǹfàní láti wà níbẹ̀, àyàfi àwọn tí Ọlọ́wọ̀ bá tún gbà láàyè (91).Àránsí (2016) tún jẹ́ kí á mọ̀ bákan náà pé ibiìṣeré onídàákọ́ńkọ́ ni Igbó Ọ̀rọ̀nṣẹ̀n tí wọ́n ti máa nṣe orò ìkádìí ọdún Igogo náà pẹ̀lú. Ó là á yé wa pé àwọn Ayóóyò àti àwòrò Ọ̀rọ̀nṣẹ̀n nìkan ni wọn máa ń kópa nínú ìṣorò náà (Àransí 2016:133).

Ibi ìṣeré olójútáyé ni òpópónà ààrinìgboro tí àwọn eégún máa ń gbà kọjá nígbà tí wọ́n bá ń yíde lákòókò ọdún eégún. Bẹ́ẹ̀ náà sì ni ojú ọjà iwájúde ọba tàbí tìjòyè míràn tí àwọn eégún náà ti máa ń pagbo eré pẹ̀lú.Òǹworan gbogbogbòò (tawotọ̀gbẹ̀rì) ni ó ní àǹfàní láti wòran àwọn egúngún ní àkókò ọdún ègúngún jákèjádò ilẹ̀ Yorùbá. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìṣeré tó máa ń wáyé ní àwọn ibi ìṣeré olójútayé wọ̀nyí ni wọ́n fi máa ń ṣe ayẹyẹ, tí wọ́n sì tún ń dánilárayá papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà ní àkókò ọdún ìbílẹ̀. Nínú ọdún Àjàlémògún ní Ìlárámọ̀kín ní tòsí Àkúrẹ́ ibi ìṣeré olójútáyé ni òpópónà tí àwọn ọmọ awo máa ń gbé èreÀjàlémògún ńlá gàgàrà gbà láti ìgbó òrìṣà náà lọ sí ààrín ọjà. Gbogbo àwọn òǹwòran á dúró sí ẹ̀gbẹ̀ẹ̀gbẹ́ òpópónà náà wọn a sì tún máa wọ́ tẹ̀lé wọn lẹ́yìn bí wọ́n bá ti kọjá wọn tán. Tìdùnnú tìdùnnú ni à wọn èrò ìwòran náà yóò sì fí máa wúre kí àwọn tun lè rí ìṣeré orò náà ní ẹ̀ẹ̀mín-ìn. Ojúmọmọ ni wọ́n máa ń ṣe é ní bí i ìyálẹ̀ta. Àránsí (2016) náà jẹ́ kí ámọ̀ pé ibi ìṣeré ojútáyé ni ibi ojúbọ Òkúta Arigidi, ojúbọ Ọ̀rọ̀nṣẹ̀n, Ugbátẹ àti Ọjà Ọlọ́pàtẹ Ògún, nínú ọdún

Igogo. Ojúmọmọ ni ìṣeré ní àwọn ibi wọ̀nyí bí Àránsí ti ṣe àlàyé. Àyàfi ibi ìṣeré Ọjà Ọlọ́pàtẹ Ògún nìkan ni ó sọ pé alẹ́ ni ìṣeré ajẹmórò ibẹ̀ máa ń wáyé, ṣùgbọ́n wọn a máa tan iná àtùpà láti ríran. Ònwòran gbogbogbòò ni ó sì ní àǹfàní láti kópa ní gbogbo àwọn ibi ìṣeré mẹ́rẹ̀ẹ̀rin.

### 4.3.3 Aṣọ Eré, Ìbòjú àti Ohun Èlò Ìṣeré Mìíràn

Àwọn aṣọ tí àwọn òṣèré máa ń wọ̀ láti ṣe ìsínjẹ àwọn ẹ̀dá ìtàn (ìyẹn àwọn òrìṣà, baba-ńlá àti ìyá-ńlá, pẹ̀lú àwọn ẹ̀mí àìrí abbl.) nínú ọdún ìbílẹ̀ ni a gbà bí aṣọ eré. Kò sí aṣọ tí à ń wọ̀ ní ojú ayé tí wọn kò lè lò bí aṣọ ere bí ó bá ti bá ìṣeré náà mu. Nínú ọdún ìbílẹ̀ a ṣe àkíyèsí pé àwọ̀ aṣọ ṣe pàtàkì, ó sì máa ń ní ìtumọ̀ alárokò nípa òrìṣà kọ̀ọ̀kan. Bí àpẹẹrẹ, aṣọ ààlà ni àṣọ Ọbàtálá àti Olóòṣà oko, Ọ̀ṣun àti Yemọja pẹ̀lúti púpọ̀ nínú àwọn orìṣà omi. Aṣọ pupa ni ti Ṣàngo, aláràbarà ni àwọ̀ aṣọ Egúngún, alábala mejì yála dúdú àti pupa tàbí dúdú àti funfun ni ti Eṣù. Màrìwò ni ìtàn ìwáṣẹ̀ sọ fún wa pé ó jẹ́ ojúlówó aṣọ Ògún, nítorí náà ní àkókò ìsọdún Ògún mọ̀rìwò títamọra a máa wà lára ìmúra àwọn aṣesíjẹ Ògún. Irú àwọn ìmúra pẹ̀lú aṣọ tí ó fi àwọn àwọ̀ òrìṣà yókù náà hàn bí a ṣe ṣàlàyé ni àwọn aṣèsínjẹ àwọn òriṣà náà máa ń wọ̀ ní àkókò ìṣeré ọdún. Irú aṣọ tí à ń lò nínú ìṣeré kọ̀ọ̀kan lè ní orúkọ àdání tirẹ̀. Ẹ̀kú tàbí àgọ̀ ni ti egúngún, àrópalẹ̀ ni ti àwọn ẹ̀yọ̀ aláfẹ́ nínú ọdún Òrìṣà Adímú lÉkòó, ìdira ni ti àwọn arugi gẹ̀lẹ̀dẹ́, gbéri, yẹ̀rì àti wàbì ni ti Ṣàngó.

Ìbòjú jẹ́ ohun èlò ìṣeré kan tó wọ́pọ̀ jùlọ nínú ọdún egúngún àti ọdún gẹ̀lẹ̀dẹ́ tàbí ẹ̀fẹ̀. Àwọn egúngún kan máa ń ru ère láti ṣe ìsínjẹ àbùdá pàtàkì kan nípa babańlá tí wọ́n fẹ́ fi hàn. Bákan náà nínú ọdún gẹ̀lẹ̀dẹ́, àwọnonígẹ̀lẹ̀dẹ́(arugi gẹ̀lẹ̀dẹ́) máa ń gbé èrerù tí wọn ó so aṣọ tàbí àwọ̀n ìbòjú mọ́. Àwọn ère tí wọ́n gbé rù, tí wọ́n sì soìbòjú mọ́ náà ni wọ́n máa ń lò láti fi pàrokò ajẹmẹ́fẹ̀ nípa àwọn ènìyàn àti ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ wọn.Oríṣiríṣi àrokò ni wọ́n máa ń fi ère tí wọ́n rù pa. Ó lè jẹ́ àfihan àwòrán ẹranko, ẹyẹ, ẹja, ejò, ọba, ẹlẹ́ṣin, ìyá àti ọmọ rẹ̀, ọlọ́pàá, òyìnbó D. O., àfáà Mùsùlùmí, àlùfáà Àgùdà, Ìbejì, alátẹ ọjà, onílù dùndún, ọdẹ, ṣọjà, alùpùpù, ojú ènìyàn tí ó ń fi oríṣiríṣi ilà ẹ̀rẹ̀kẹ́ tí àwọn Yorùbáń kọ hàn,ọ̀dọ́kọ àti ọ̀falè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí ó ti hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ tí a tọ́ka sí wọ̀nyí,àwọn ère tí wọ́n so ìbòjú mọ́ náàlè jẹ́ àmì tí ó ń tọ́ka sígbàgbọ̀ tàbí ojú àmúwayé Yorùbá kan tàbí òmíràn, tàbí kí wọ́n jẹ́ àrokò nípa ìtàn àtijọ́ tàbí ti ìṣẹ̀lẹ̀ ọ̀rọ̀ tó ń lọ lọ́wọ́lọ́wọ́láwùjọ,(wo Ìbítókun 1993 àti Lawal 1996). [Wa orí ìtàkùn àgbáyé, pàápàá You Tube fún /gelede mask/]Ère tí í máa wà lára ìbòjú egúngún àti àwọn òrìṣà míràn lè jẹ́ àmì ìdámọ̀ egúngún tàbí ti àwọn òrìṣà náà, ó sì lè jẹ́ ìpàrokò ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ náà. A lè rí adé ìṣẹ̀ǹbáyé tí ọba máa ń dé ní àkókò ọdún ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìbòjú, nítorí pé ìlẹ̀kẹ̀ janwọn janwọn etí adé náà a máa bo ọba lójú.

Lára àwọn ohun èlòìṣeré ìléwọ́ tí àwọn òṣeré máa ń mú dání nínu eré oníṣe ọdún ìbílẹ̀ ni ìrùkẹ̀rẹ̀, ọ̀pá àṣẹ,tí ó bá jẹ́ ọba tàbí ti òrìṣà tí ó bá jẹ́

bàbálórìṣà. Ẹlẹ́gùn Ṣàngó yóò mú oṣé àti ṣẹ́ẹ́rẹ́ dání; àtòrì sì ni ti egúngún. A lè rí igbá tí a kó nǹkan ìrúbọ àti àwọn ohun ìrúbọsí, bí obì, ẹja, eku, orógbó, iyọ̀, oyin ataare abbl., náà bí ohun elò ìṣeré. Bí ọdẹ tàbí jagunjagun bá wà lára àwọn aṣèsínjẹ a kò ní í ṣàìrí ìbọn, idà, àdá, ọkọ̀, ọfààti ọrun gẹ́gẹ́ bí ohun elò ìṣeré ìléwọ́. Bákan naáà ni a lè rí àwọn ohun èlò tilùtìfọn alámúlọ́wọ́ bí i apẹ́pẹ́, agogo, aro, ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ àti ferè bí i èkùtù, tòrò-mágbè, pẹ̀lú ìlù bí i dùndún, bàtá, bẹ̀ǹbẹ́, àti bàtá-koto pẹ̀lú kósó náà bí ohun èlò ìléwọ́. Àwọn ohun èlò mìíràn tí a máa ń gbé sí ibi ìṣeré fún àmúlò àwọn eléré bí i ẹní, ìtẹ́ ọba níbi tí a bá ti lò wọ́n,odó Ṣàngó àti oríṣiríṣi àwọn ìlù ńláńlá bí i gbẹ̀du (ọba) ìgbìn (Ọbàtálá),àti àgbá (Ọ̀ràǹfẹ̀ ní Oǹdó) arago (Òrìṣa Adímú ní Èkó) náà jẹ́ oríṣi ohun èlò ìṣeré kan. Lára àwọn ohun èlò ìṣeré wọ̀nyí lè jẹ́ àmì òrìṣà tàbí ti ìdámọ̀ ẹ̀dá ìtàn tí à ń sín jẹ. Bí àpẹẹrẹ, àdá, idà, ìbọn, ọ̀kọ̀, jẹ́ àmì òrìṣà Ògún, adé ṣẹ́ṣẹ́-ẹfun jẹ́ àmi Òríṣà Òkè, oṣé àti ṣẹẹrẹ sì jẹ́ àmì Ṣàngó.

### 4.3.4 Àhunpọ̀ Ìtàn àti Ìṣẹ̀lẹ̀ Inú Eré

Nínú ọ̀pọ̀ àwọn eré òde òní, àhunpọ̀ ìtàn máa ńlọ tààrà. Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwọn eré bẹ́ẹ̀ máa ń tò tẹ̀léra nísísẹ̀ntẹ̀lé níbàámu pẹ̀lú bí wọn ṣe máa ń tẹ̀léra lójú ayé. Ṣùgbọ́n irú àhunpọ̀ ìtàn tààrà bẹ́ẹ̀ ṣọ̀wọ́n nínú ìṣeré àwọn orò àti ọdún ìbílẹ̀ lápapọ̀.Ètò ṣísẹ̀ntẹ̀lé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ọdún ìbílẹ̀ lè má jẹ́ àgbékalẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn tààrà kan ní pàtó, ṣùgbọ́n ìkọ̀ọ̀kan wọn máa ń sábàá tọ́ka sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn ìwáṣẹ̀ tàbí ti akọnikàyéfì kan nípa òrìṣà tàbí akọni àtijọ́ tí a fi ọdún ìbílẹ̀ náà sọrí. Lábalalábala ni àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà máa ń tò léra wọn. Ìyẹn ni pé a lè má rí àsopọ̀ gúnmọ́ kan láàrin wọn. Nípa ìlò àmì alárokò sì ni ìtọ́kasí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwọn ìtàn ìwáṣẹ̀ àti ti akọni kàyéfì náà máa ń jẹ́. Bí òǹwòran kò bá sì ṣèwádìí, ìmọ̀ léréfèé ni yóò ní; kò lè ní òye kíkún nípa ìtumọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà.

Oríṣiríṣi ni àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ajẹmórò tí í máa wáyé nínú ìṣeré ọdún ìbílẹ̀. Lárá wọn ni ìfọ̀nùmọ́, ìṣídeàti ìkédeọdún,ìsínjẹ aáwọ̀ tàbí ìtakora,ìrubi-lọàti àwọn ìrúbọ mìíràn abbl.Ìṣeré orò ni ìkọ̀ọ̀kan àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà máa ń jẹ. Àtòjọ gbogbo rẹ̀ ni ó ńdi ọdún ìbílẹ̀. Lára àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ajẹmọ́nà tí wọ́n fi ń ṣe ìgbékalẹ̀ àwọnìṣorò náà ni títò lọ́wọ̀ọ̀wọ́ yí ìlú ká, ẹkẹ mímù, ìlù lílù, ijó jíjó àti àwọn ọnà afọ̀ mìíràn bí i, orin kíkọ, ohùn pípè, ìsọ̀rọ̀ǹfèsì, ìkíni àti ìṣèbà tàbí ìkọsẹ̀, ìre ìwúre, ìkàrò, ẹ̀kà kíkà tàbí oríkì kíkì abbl.
Ẹ jẹ́ kí á ṣe àpẹẹrẹ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìṣorò bí i mẹ́ta tí í máa wọ́pọ̀ nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá. Àkọ́kọ́ ni orò ìfọ̀nùmọ́. Èyí jẹ́ pàtàkì lára orò ìpalẹ̀mọ́fún ọ̀pọ̀ ọdún ìbílẹ̀. Ohun tí wọn máa ń ṣe nínú orò yìí ni ọnà igbó òrìṣà yíyẹ̀, ilé òrìṣà àti gbogbo agbègbè gbígbá mọ́ tónítóní, tí ohun gbogbo yóò sì wà ní mímọ́, tí kò ní í sí ẹ̀gbin kankan ní àyíká, àtúnṣe yóò wà sí ojúbọ, ilé òrìṣà àti ilé ọba bí ó bá ti tọ́, tí ó sì yẹ.Àpẹẹrẹ ni orò alẹ̀ gbígbá nínú ọdún Ọ̀ràǹfẹ̀ ní Oǹdó, nígba tí àwọn obìnrin ilé Ṣọ̀rà, tí ó jẹ́ abọrẹ̀ òrìṣànáà yóò gbá gbogbo ilẹ̀ agboolé láti ọjọ́rọ̀ (4pm) ọjọ́ kìn-ín-ní ọdún náà di kò-ríni-kò-mọni ọjọ́ kejì (3am) (Fasehùn 2017). Bí Faséhùn ti fi yé wa síwájúsí i, irú títún ojúbọ Ògún àti gbogbo ìlú ṣe

báyìí a máa wáyé nínú ọdún Ògún láàrín ọjọ́ kejì sí ọjọ́ keje ọdún naáà. Bákan náà bí Fáséhùn (2017) ti sọ,nínú ọdún ọba ní Oǹdóorò ìkọ́lé ọba a máa wáyé gẹ́gẹ́ bí ara ìpalẹ̀mọ́ fún ọdún náà, nígbà tí wọn yóò tún àfin ṣe dáradára. Ní ayé àtijọ́ tí ó jẹ́ pé koríko ni wọ́n fi ń bo ilé, ó là á yé wa pé wọn yóò tún ilé ọba bò, wọn ó sì ṣe gbogbo rẹ̀ mọ́ tóntóní. Irúfẹ́ orò yìí kan náà ni a lè pe orò ọ̀fọ̀nràn níbẹ̀rẹ̀ ọdún edì ní Ilé-Ifẹ̀. Wọn yóò fi igi ẹtà dáná sîìkòríta ìkòríta àti ìwájú ilé, èéfín yóò sì máa rú túú káàkiri gbogbo àárín ìgboro. Ìgbàgbọ́ àwọn ará Ilé-Ifẹ̀ ni pé èéfín yìí yóò fín gbogbo àwọn ẹ̀mí burúkú kúrò ní àárín ìlú. A lè sọ wí pé lára orò ìfọ̀lúmọ́ náà ni òrò ìwopópó tí wọn maá ńfi bẹ̀rẹ̀ ọdún Ọ̀ṣun ní Ọṣogbo. Àtaója (ọba Oṣogbo) pẹ̀lú àwọn ìjòyè àti olorì ni yóò jọ kọ́wọ̀ọ́ rìn yí àwọn òpópónà kan ní àárín ìlú láti ṣàbẹ̀wò ìmọ́tótó wọn.

Ọ̀pọ̀ ọdún ìbílẹ̀ ni wọ́n ti máa ń ṣe ìsínjẹ ìjàkadì tàbí ẹkẹ láti fi parokò nípa aáwọ̀ ìtàkora tàbí èdè àiyedè kan tí ó ti wáyé rí nínú ìtàn ilú, tí ó sì jẹ mọ́ ọdún ìbílẹ̀ tí wọn ń ṣe. Àpẹẹrẹ irúorò ìsínjẹ bẹ́ẹ̀ a máa wáyé nínú ọdún Ọbàtálá láàrin àwòrò Ọbàtálá méjì, Olúuwin àti Ajagẹmọ ní Ẹdẹ;nínú ọdún Ońmọ̀ká ní Ọ̀fà, láàrin Ọlọ́fà àti Eésà, àgbà ìjòyè rẹ̀ kan; nínú ọdún Olóókù ní Òkukù láàrin Olókukù àti àwòrò olóókù àti nínú ọdún edì ní Ilé Ifẹ̀, láàrín àgbà ìjoyè méjì, Ọbalúfẹ̀ àti Ọbaláàyán.  Nínú ọdún Ògìyán ní Èjìgbò ọrẹ́ jíjà ni àárín àwọn ọ̀dọ́ àdúgbò Òkè Pópó àti ìsàlẹ̀ Ọsọlọ̀ ni wọ́n ti máa ń ṣe ìsínjẹ yìí (Ògundèjì 1995, 2014). Nínú ọdún Igogo ní Ọ̀wọ̀ ìdíje ìjà a máa wáyé láàrin àwọn ọ̀dọ́. Bí èyí tilẹ̀ jẹ́ ìdárayá bí Àránsí ti tọ́ka sí i, àwá lérò pé a tún lè rí i bí àrokò ìtọ́kasí aáwọ̀ owú jíjẹ tí ó wáyé láàrin àwọn olorì Ọlọ́wọ̀ Rẹ̀nrẹngẹnjẹ̀n, tó mú kí àwọn olorì yókù dẹ́jàá àwọn èèwọ̀ Ọ̀rọ̀ṣẹ̀n,àáyò ọba. Èyí ni ó sì mú alágbara obìrin náà sá kúrò ní Ọ̀wọ̀ tí ó sì di akúnlẹ̀bọ tí wọn ńrántí rẹ̀ di òní olónìí. (Àránsí: 2016). Ohun tí ó mú kí á fi ojú yìí wo ìdíje ìjàkadì náà ni ti àwọn obìnrin tí wọn máań kópa nínú rẹ̀. Ní ilẹ̀ Yorùbá obìnrin kì í sábàá díje eré ìjàkadì.A lérò pé nítorí ìjà orógún lẹ́ẹ̀dẹ̀ (tí ó jẹ́ pé àwọn obìnrin ni ó kàn jù lọ) ni ọ̀rọ̀ inú ìtàn ìwáṣẹ̀ náà ni ó mú kí a gba obìrin láyè láti díje ìjàkadì nínú ọdún ìbílẹ̀ tí à ń ṣe ní ìrántí akọnibìnrin náà, àní Ọ̀rọnṣẹ̀n.

Oríṣi ìṣẹ̀lẹ̀orò kan tí í máa tún wà nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ kan ní Ìlẹ̀ Yorùbá ni orò ríru ibi lọ̀.  Èyí jẹ mọ́ìfènìyànrúbọ ní ayé àtijọ́. Irú ẹni bẹ́ẹ̀ kì í sábàá jẹ́ ọmọ onílẹ̀; àlejò ni ó máa ń sábàá jẹ́. Ìdí nìyẹn tí wọ́n fi tún máa ń pè é ní olùwọ̀. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé a kò gbọdọ̀ fi ọmọ onílẹ̀ bọ ilẹ̀. Ohun kan tí a ní láti kíyèsí ní ibí ni pé ìfènìyànṣetùtù lè wáyé láìjẹ́ pé irú ẹni bẹ́ẹ̀ jẹ́ arubi. Gbogbo ẹni tí wọn fi rúbọ ni olùwọ̀, ṣùgbọ́n olùwọ̀ tí ó jẹ arubi tún yàtọ̀.Kí wọ́n tó fi olùwọ̀ tí ó jẹ́ arubi ṣètùtù wọn yóò di ẹrù ìdọ̀tí rùú gẹ́gẹ́ bí àrokò fún ibi bí i ikú àrùn, òfò, àṣeèrí abbl. Gbogbo èyí ni  wọ́n gbàgbọ́ pé àrubi yóò gbé lọ sí ọ̀run tí wọn bá ti fi rúbọ. Ìdí nìyí tí wọ́n tún fi máa ń pè é ní agbẹ́bọyọ́run(Àránsí, 2016). Ní ode òní tí kò sí ìfèniyànrúbọ mọ́ ẹran bí i àgbò tàbí ẹ́nlá ní wọ́n máa ń lò dípò.

Nínú ọdún edì, Tele ni orúkọ tí wọn ń pe arubi.Nígbà tí wọ́n bá ń mú un lọ sí ìgbó Mọrèmi, àwọn ènìyàn tí wọn dúró ní ẹ̀gbẹ́ òpópónà yóò máa taka òfò dànù, wọn óò máa ré ibi lé Tele lórí wọn óò máa ni "Ikú yooyóòyo! Àrùn yooyóòyo! Àṣeèrí yooyóòyo," tí a lè túmọ̀ sí pé kí Tele máa gbé ikú, àrùn, òfò àti àṣeèrí lọ. Ẹnikẹ́ni kì í báwọn wọgbó Mọrèmi fún ètùtù náà. Ṣùgbọ́n ohun tí a gbọ́ ni pé, lóde òní, Tele yóò ré gbogbo ẹrù ibi orí rẹ̀ dà sórí ẹ́nlá tí wọn yóò pa dípò rẹ̀. Irú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí kan náa máa ń wáyé nínú ọdún Ẹ̀yọ̀ ní àtijọ́ àti ọdún Igogo ni Ọ̀wọ̀ (Ògúndèjì, 1995 àti Àránsí 2016). Nínú ọdún Ẹ̀yọ̀, Adímú ni wọn máa ń ré ibi ìlú lé lórí, ṣùgbọ́n òun yóò ré e sórí Ògunran tí wọn yóò fi ṣe ìrúbọ náà. Ògúnran kì í kópa nínú ọdún náà mọ́ lóde òní nítorí ìkáṣẹ̀ńlẹ̀ ìfènìyàn-rúbọ (Ọ̀sanyìn, 2004). Gẹ́gẹ́ bí Àránsí (2016) náà sì ti fi yé wa àgbò ni wọn máa ń lò nínú ọdún Igogo gẹ́gẹ́ bí i agbẹ́bọyọ́run, inú Igbó Ọ̀rọ̀nṣẹ̀n, tí ẹnikẹ́ni, kì í bá àwọn àwòrò Ọ̀rọ̀nṣẹ̀n àti Ayóóyóò wọ̀ ni wọn ti máa ń pa á fi ṣètùtù.

## 4.3.5 Ìsọ̀rọ̀ńfèsì, Orin, Ìlù àti Ijó

Ìsọ̀rọ̀ńfèsì, máa ń mọ níba nínú ọdún ìbílẹ̀. Kì í sábà ju bí i ìbéèrè àti ìdáhùn ṣókí ṣókí tàbí àwọn ọ̀rọ̀ àsọgbà kéékèké lọ. Orin ìlù àti ijó ni wọn maá ń lò láti fi dí àlàfo tí ìbá wànínú ìbánisọ̀rọ̀ àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà. Oríṣiríṣi orin tí ó bá àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìṣorò inú àwọn ọdún ìbílẹ̀ kọ̀ọ̀kan mu ni wọ́n máa ń kọ sí wọn. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ nínú ọdún Ọ̀ṣun, àwọn orin tí ó máa ń fi agbára òrìṣà Ọ̀ṣun hàn ni wọ́n máa ń kọ. Àwọn àpẹẹrẹ kan nìyí:

1. Lílé: Ẹ kóre Yèyé
   Ègbè: Ẹ kóre Yèyé Ọ̀ṣun
   Lílé: Ẹ kóre Yèyé
   Ègbè: Ẹ kóre Yèyé Ọ̀ṣun
   Lílé: Ọlọ́mọ nìyá
   Ègbè: Ọlọ́mọ nìyá àwa

2. Lílé: Ọ̀ṣun ń kọ́mọọ́ bọ̀ o
   Ègbè: Ọ̀ṣun ọlọ́mọ yọyọ
   Lílé: Ọ̀ṣun ń kọ́mọọ́ bọ̀ o
   Ègbè: Ọ̀ṣun ọlọ́mọ yọyọ

Àgbára tí òrìṣà Ọ̀ṣun ní ni láti fúni lọ́mọ. Èyí sì súyọ nínú àwọn orin ọdún Ọ̀ṣun tí a kọ lókè. Bí wọ́n ṣe ń kọrin yìí ni wọn yóó máa lùlù tí wọn yóó sì máa jó. Ìlù ìgbìn ni wọ́n ń lù nínú ọdún Ọbàtálá, bàtá ni ilú tí a máa ń lù nínú ọdún Ṣàngó, àgẹ̀rẹ̀ ni ìlù tí àwọn ológùn-ún ń lù, àpèsìn àti àgẹ̀rẹ̀ ni ìlù tí wọn ń lù nínú ọdún Orò, ìpèsè, àràn àti agogo ni ti ọdún ifá, àgbá àti ọ̀gwẹ́gwẹ́ ni ti ọdún Ọ̀ràǹfẹ̀ ní Òǹdó (Fáséhùn 2017), Òsígì, umọba, agogo, ṣọ̀kọ̀rọ́ghọ̀ àti ùwo ni ti ọdún Igogo ní Ọ̀wọ̀ (Àránsí 2016). Bí ìlù bá ṣe lọ sí ni a ṣe ń jíjó rẹ̀ nínú ọdún ìbílẹ̀. Ijó le jẹ́ àdájó tàbí àjọjó. Àdájó ni ijó tí àwọn ọmọ ìṣòrò máa ń jó nínú ìran

Kúṣẹndí ní agbègbè Ìdọ̀fin ní ìlú Igbó-Ọrà lásìkò ọdún Orò. Bákan náà, àpẹẹrẹ ijó nínú ọdún ìbílẹ̀ ni èyí tí ó máa ń wàyé ní Ìjẹ̀bú-Ìlọ̀nẹ̀ ní tòsí Ìjẹ̀bú Òde nígbà tí àwọn ẹlẹ́gùn òrìṣà Yemojì bá ń jó ijó adájó nínú ọdún Yemojì (Ògúndèjì, 1992).

### 4.3.6 Ìwúlò

Oríṣiríṣi ọ̀nà ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń gbà wulò ní àwùjọ. Bí wọ́n ti ń lò wọ́n fún ìsìn àwọn òrìṣà, tí afi wọ́n gbé oríyìn fún àwọn akọni àtijọ́,tí a sì fi ń ṣe ìrántí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mánigbàgbé nínú ìtàn ìṣẹ̀ǹbáyé àwùjọ, náà ni a fi ń dáni láráyá.Yàtọ̀ sí àwọn èyí a tún máa ń lò wọ́n láti wúre fún ìfọ̀kànbalẹ̀ àti àlàáfíà pẹ̀lú ìtẹ̀síwájú ní àwùjọ lápapọ̀.Àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà tún wúlò fún ṣíṣe okùnfà ìrẹ́pọ̀, ìfọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú ìṣọ̀kan ní àárín àwùjọ. Wọ́n a sì máa fi ààyè gba kí ọrọ̀ ajé àwùjọ ó tún rú gọ́gọ́ sí i. Ju gbogbo rẹ̀ lọ wọ́n tún jẹ́ ọnà ìgbáṣà lárúgẹ àti ìṣàṣà àti àwọn ọnà pẹ̀lú ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ wọn lọ́jọ̀ fún ìran tí ó ń bọ̀. Ìdí níyí tí kò fi yẹ kí wọ́n parun. Bí wọ́n bá parun gbogbo àwọn àǹfààní wọ́nyí ni ìran tí ń bọ̀ yóò pàdánù.

## 5.0 ÌSỌNÍṢỌKÍ

A ti ṣe àgbéyẹ̀wò níwọ̀nba nípa àríyànjiyàn àwọn onímọ̀ lórí jíjẹ́ eré oníṣe ọdún ìbílẹ̀ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. A fi hàn pé ojú ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí àwọn aláríyànjiyàn náà fi wo ọ̀rọ̀ ló fà á. Àwọn tí kò fara mọ́ ọn ń lo òdiwọ̀n àbùdá eré oníṣe ilẹ̀ Yúróòpù, èyí tó yàtọ̀ sí tí Áfíríkà. Akì í pààlà sí àárín iṣẹ́ ọnà àti ìwúlò rẹ̀ní Áfíríkà bí wọn ti ń ṣe ní Yúróòpù. A tọ́ka sí i pé ohun tí ó mú wa gba àwọn ewì alohùn tí à ń lò fún ìsìn òrìṣà tàbí láti jẹ́ iṣẹ́ mìíràn tí à ń lò wọ́n fún, náà ni yóò mú wa gba ọdún ìbílẹ̀ tí à ń mú lò láti jẹ́ oríṣiríṣi àwọn iṣẹ́ láwùjọ bí eré oníṣe.

Lẹ́yìn èyí ni a sọ̀rọ̀ àwọn àbùdá eré oníṣe lápapọ̀, kí á tó wá jíròro nípa ìjẹyọ wọn nínú ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá. Lára àwọn àbúdá tí agbéyẹ̀wò ní àṣèsínjẹ àti ẹ̀dá ìtàn, ibi ìṣeré, ibùdó ìtàn àti òǹwòran, aṣọ eré, ìbòjú àti àwọn ohun èlò ìṣeré mìíràn, àhunpọ̀ ìtàn àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ náà, pẹ̀lú ìsọ̀rọ̀ǹfèsì, orin ìlù àti ijó. A kò sì ṣalaì mẹ́nu ba ìwúlò ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ náà.

Ohun kan tí ìjíròrò inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ ni pé a lè fi ojú eré oníṣe wo àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá láàyè ara tiwọn nítorí wọ́n ní àbùdá eré oníṣe nínú. Kò pọn dandan kí àwọn àbùdá náà ó ṣe rẹ́gí pẹ̀lú ti àwọn ará Yúróòpù tàbí ti ilẹ̀ míràn gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àlàyé níbẹ̀rẹ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ÀMÚṢE

1. Ní ṣokí,ṣe àlàyé àríyànjiyàn nípa bóya eré oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀ tàbí kì í ṣe eré oníṣe.
2. Ní ṣókí, kín ni ìyàtọ̀ láàrin: aṣèsínjẹ àti ẹ̀dá ìtàn; ibi ìṣeré àti ibùdó ìtàn?
3. Jíròrò lóri oríṣi ìṣẹ̀lẹ̀ méjì tí ó máa ń jẹ yọ nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá.
4. Ṣàlàyé àwọn ọ̀nà mẹ́ta tí o lérò pé eré oníṣeọdún ìbílẹ̀ gbà wúlò ní àwùjọ.
5. Kín ni ìbòjú? Kọ àròkọ kékeré kan lórí ìmúlò rẹ̀ nínú ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Abímbọ́lá, K. 2006. *Òwe, Àkànlò Èdè àti Àṣàyàn Ọ̀rọ̀ Yorùbá,* Tìmì Àgbàlé Ventures, Ìlọrin.

Adédèjì, J.A. 1966. “The Place of Drama in Yorùbá Religious Observance”, *Odù* 13. No 1. 88-94.

Adedèjì, J. A. 1969, The Alárìjó Theatre: Astudy of a Yorùbá Theatrical Art From ìts Earliest Beginnings till Present Times,Àpilẹ̀kọ Àkọgboyè Ìmọ̀ Ìjìinlẹ̀ PhD., tí akò tẹ̀ jáde fún títà, Yunifásitì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Àránsí, A. O. 2016,Ojú Àmúwayé Yorùbá ní Ìlànà Eré Oníṣe Nínú Ọdún Igogoní Ìlú Ọ̀wọ̀, , Spectrum Books Ltd.,Ìbàdàn.

Beier, U. 1967 “Yorùbá Theatre” nínú Ulli Beier (olóòtú) *Introduction to African Literature: An Anthology of Critical Writings on African and Afro-American Literature and oral Tradition,* Longman Group,London.

de Graft, J.C. 1976, “Root in African Theatre,” *African Literature Today,* No. 6. o.i.1- 25.

Echeruo, 1971 “The Dramatic Limits of Igbo Rituals,” *Research in African Literatures.* Fol. 4, Nọ 7, o. i. 24 – 27.

Fáséhùn, M. A. 2017 Dramatic Features of Ọ̀ràmfẹ̀, Ògún and Ọba Festival in Oǹdó Kingdom, Nigeria, Àpilẹ̀kọ Àkọgboyè Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ PhD.tí a kò tẹ̀ jáde fún títà., Yunifásítì Ìbàdàn, Ìbàdàn. .

Finnegan, R. 1970. *Oral Literature in Africa,* Oxford University Press,Nairobi.

Ìbítókun, B. M. 1993 *Dance as Ritual, Drama and Enterrtainment in the Gẹ̀lẹ̀dẹ́ of Kétu- Yorùbá Sub-group in West Africa: A Study in Traditional African Feminism*. Ọbáfẹ́mi Awólọwọ̀ University Press,Ilé-Ifẹ̀.

Lawal, B. 1997 *The Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Spectacle: Art, Gender and Social Harmony in An African Culture*, University of Washington Press,Seatle and London.

Ogunba, O. 1978. "Traditional African Festival Drama", Ogunba, O. Àti Ìrèlé, A., *Theatre in Africa*, Ìbàdàn University Press, o.i. 3-26,Ìbàdàn.

Ogunba, O. 2000. "Stage and Staging in Yorùbá Ritual Drama," nínú Délé Láyíwọlá *African Theatre in Performance: A frestrifsch in Honour of Martin Banham*, Hardwood academi Publishers o. i.54 – 66,Australia.

Ògúndèjì, P.A . 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. University of Ìbàdàn Centre for External Studies,Ìbàdàn.

_________ 1992. *Yorùbá Drama 1(Eré Oníṣe Yorùbá 1*). Centre for External Studies University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

__________ 1995 "Yorùbá Drama and Religion: the Pre- and Post Colonial Situations," *Oríta: Ìbàdàn Journal of Religious Studies*, Fol. XXVI, No1 – 2, o. i. 100 – 112.

____________ 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigeria Example.* Atlantic Books,Ibadan.

___________ 2005. "Functions and Forms of Traditional Theatre Practice in Nigeria" nínú S. Adémọ́lá Àjàyí (olóòtú), *African Culture and Civilisation* in Atlantis Books and Ìbàdàn Cultural Studies Group, o. i. 211 – 245, Ìbàdàn.

Ọ̀sanyìn, B.2004. *Adámúòrìshà Play of Lagos: A Study in ritual Drama*, Lagos: Deocraft communications

Rótìmí, O. 1968. "The Drama in African Ritual Display", *Nigeria Magazine,* No. 99, o.i. 329-330, ó tún wà nínú Ògúnbíyí, Y. 1981. *Drama and Theatre in Nigeria: A Critical Source Book,* Nigeria Magazine Publication, Lagos.

# ÌPÍN5 ERÉ ONÍṢẸ II: EÉGÚN ALÁRÉ

## AKÓÓNÚ


1.0 Ìfáárà
2.0 Èròńgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Àbùdá Ìṣeré Oníṣe
4.1.1 Eégún Aláré bí IṣẹÌran/ Ìdílé
4.1.2 ẸgbẹEléré, Àwọn Òṣèré àti Ọnà Wọn
4.1.3 Ìgbéréká
4.1.4 Ètò ÌṣeréLójú Agbo Eré
4.1.4 1 Ìṣíde
4.1.4.2 Eré Oníṣe
4.1.4.3 Ìkádìí
4.2 ÀpẹẹrẹIdán/ Eré Díẹ̀
4.2.1 Idán Ajẹmórìṣà
4.2.2 Idán Ajẹmọ́wà ÌbàjẹÀwùjọ
4.2.3 Idán Àparelé
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Àmúṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́sí


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Oríṣiríṣi orúkọ ni àwọn onímọ̀ ti pe eégún aláré. Lára àwọn orúkọ yìí ni egúngún apidán, egúngún alárìnjó àti egúngún lábalà. Bí a bá wò ó dáradára, a ó rí i pé kì í ṣe idán nìkan ni àwọn eléré yìí máa ń pa; wọ́n ń pẹ̀ṣà, wọ́n ń jó, wọ́n ń fi aṣọ aláràbarà dárà, wọ́n sì ń tàkìtì náà. Ó hàn gbangba pé orukọ‘egúngún apidán’ tí a fi pè wọ́n,ìkan péré lára àwọn ọnà ìṣeré wọn ni. Kódà Ẹyọ kọ̀ọ̀kan nínú àwọn ọnà ìṣeré wọn ni ìkọ̀ọ̀kan àwọn orúkọ yòókù náà ń tẹnu mọ́. Idań pípa ni ‘apídán’ ń tẹnu mọ; ijó jíjó ni ‘alárìnjó’ ń pe àkíyèsí sí; aṣọ aláràbarà àwọn elégún sì ni ‘lábalà’ ń tọ́ka sí. Kò sí èyí tí ó kó gbogbo ohun tí wọ́n ń ṣe pọ̀. Lọ́nà míràn ẹ̀wẹ̀,‘alárìnjó’ tí a pè wọ́n jẹ́ orúkọ tí a fi ń tàbùkù wọn ní ìgbàkan rí, bí Adédèjì(1978) ṣe pe àkíyèsí sí. Orúkọ tí ó kógo já tí àwọn aláré náà sì máa ń pe ara wọn jù lọ ni ‘eégun aláré’. Orúkọ yìí kó gbogbo ọnà eré wọn tí a óò yẹ̀wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yí pọ̀, òun sì ni a yàn fún lílò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

Kò sí àríyànjiyàn kankan lórí bóya eré oníṣe nieégún aláré tàbí kì í ṣe eré oníṣe, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìwọ̀nba náà ni ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì àti àhunpọ̀ inú rẹ̀ fi lọ̀ọ̀rìn ju ti ọdún ìbílẹ̀ lọ. Ṣùgbọ́n ohun kan tí ó dájú ni wí pé ìdárayá jẹ́ ohun àkọ́kọ́ nínú àmojúsùn ìgbékalẹ̀ rẹ̀.Ipò kejì ni a lè sọ pé ìdániláráyá kó nínú ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ nítirẹ̀. Láti inú ìṣoròàwọn eléégún àti ọdún ìbílẹ̀

eégún náà ni eégún aláré ti dìdelẹ̀. Èyí ló fà á tó fi jẹ́ pé àbùdá ajẹmórò tàbí ìjọsìn orìṣà egúngún kò ṣe tîì kásẹ̀ nílẹ̀ tán nínú ìṣetò ìṣeré egúngún aláré. Ògúndèjì (2000, 2005) ṣe àlàyé pé eré oníṣe tí à ń yọwọ́ orò kúrò lọ́wọ́lọ́wọ́,ṣùgbọ́n tí a kò tîì yọwọ́ àbùdá ìjẹmórò náà tán pátápátá nínú rẹ̀ ni eégún aláré jẹ́. Ṣùgbọ́n o, bí ati tọ́ka sí i, ìjẹmórò inú rẹ̀ kéré jọjọ sí tàwọn oríṣìí egúngún mìíràn tí kì í ṣe eégún aláré.Ohun pàtàkì tí à ń tẹnu mọ́ ni pé, ìdánilárayá ni àbùdá tó rinlẹ̀ jùlọ nínú ìṣeré eégún aláré; kì í ṣe orò egúngún ni ó hànde jù. Kódà a lè sọ pé abẹ́nú ni ìjẹmoròrẹ̀ wà. Ó yẹ kí á tọ́ka sí i pé láti inú àwọn iṣẹ́ Adédèjì (1969, 1978) ni a ti mú púpọ̀ nínú àwọn ohun tí a sọ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, Òun ni ẹni tí ó kọ́kọ́ ṣe iṣẹ́ ìwádìí tí ó rinlẹ̀ lórí eégún aláré.

## 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó ti lèsọ irú eré oníṣe tí eégún aláré jẹ́. O ó lèjíròrò nípa,bí eégún aláré ṣe jẹ́ iṣẹ́ ìdílé, àwọn ẹgbẹ́ eléré eégún aláré pẹ̀lú àwọn òṣèré àti ọnà ìṣéré wọn. O ó sì lè ṣàlàyé nípa àwọn àbúdá ìṣeré eégún aláré bí ìgbéréká, ètò ìṣeré, kí o sì ṣe àwọn àpẹẹrẹ idán egúngún aláré díẹ̀ díẹ̀.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Orúkọ wo ni àwọn Yorùbá máa ń pe ìdílé eléégún?
2. Àwọn ọnà ìṣeré wo ni ó wà nínú ìṣeré àwọn eléégún aláré? Àwọn wo ni obìnrin kì í ṣe níbẹ̀?
3. Ṣe àdàkọ orin eléégún aláré kan tí o mọ̀, kí o sì sọ igbà tí wọn máa ń kọ ọ.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Àbùdá ìṣeré

Kí o baà lè jíròrò nípa eégún aláré gẹ́gẹ́ bí oríṣi eré oníṣeàbáláyé àwọn Yorùbá dáadáa, a ó ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá àdání rẹ̀ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Àwọn àbúdá tí a óò gbé yẹ̀wò ni éégún aláré bí iṣẹ́ ìran/ ìdílé, àwọn òṣèréeégún aláré àti ọnà wọn, ìgbéréká wọn àti ètò ìṣeré wọn. Ní àfikún a ó ṣe àgbèyẹ̀wòàpẹẹrẹ eré wọn díẹ̀.

#### 4.1.1 Eégún aláré bí iṣẹ́ ìran/ ìdílé

Àbùdá kan pàtàkì tó ya ìṣeré eégún aláré sọ́tọ̀ ni pé iṣẹ́ ìran/ìdílé ni.Ìlànà iṣẹ́ ìran, ẹbí tàbí ti ìdílé wà nínú àṣà àwọn Yorùbá. Àwọn iran Onírèsé ní í fíngbá, àwọn àyàn ní í lùlù, àwọn Ajíbógundé ní í gbẹ́gi lére, àwọn Ìrèmògún ní í rọ irin (alágbẹ̀dẹ), bẹ́ẹ̀ ni o sì jẹ́ wí pé ìran àwọnOlógbojò/ Ológbìn-ín tí a tún mọ̀ síỌlọ́jẹ̀ tàbí Ọ̀jẹ̀ní kúkúrú ní ó máa ń ru ẹ̀kú eégún tí wọn sì máa ń jẹ́ eléégún aláré. Àwọn ni wọ́n maá ń jẹ́ orúkọ bí í

Ọ̀jẹ̀rìndé, Ọ̀jẹ̀labí, Ọ̀jẹ̀fúnnkẹ́, Ọ̀jẹ̀rínú, Ọ̀jẹ̀rìnọ̀lá abbl. Níwọ̀n ìgbà tí iṣẹ́ náà ti jẹ́ iṣẹ́ ìdílé àwọn Baba ní í máa fi lé àwọn ọmọwọn lọ́wọ́. Eléyí kò sọ pé ẹni tí kì í ṣe abílọ́jẹ̀ náà kò lè kọ́ iṣẹ́ náà ṣá. Irú àwọn yẹn ni "aláwọ̀ṣe-ọ̀jẹ̀" tí a tún lè dà pè ní ọ̀jẹ̀wùmí nígbà tí a lè da àwọn ọmọ abílọ́jẹ̀ pè ní ọ̀jèdìran. Àwọn ọmọ abílọ́jẹ̀ a máa fi iṣẹ́ ìran wọn yí yangàn nígbà míràn tí wọ́n bá pẹ̀ṣà bí i ti ìsàlẹ̀ yí:

Bàbá ló kọ́mi lédè mo mèdè
Baba ló mà kọ́mi lẹ́ṣà
Mo mú lẹ́nu ó jabẹ lọ
Mo ṣòwò ètè rọjà Akèjì
Òwò tí mò ń ṣe nìyá kọ̀mí sí
Baba ló gbémi lórí ẹṣin
Lónìí ni n ó relé àwọn baba mi
Onílàǹlá ọmọ afiṣán lànà ìgbàlẹ̀

Nínú ẹ̀ṣà òkè yìí, òṣèré egúngún aláré yìí tọ́ka sí i pé bàbá òun ló kọ́ òun lẹ́ṣà tí òún fi di gbajúmọ̀. Òhun tí à ń pe àkíyèsí sí ní ìhín ni pé bàbá apẹ̀ṣà náà ló kọ́ ọ ni iṣẹ́ eré eégún aláré, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò dùn mọ́ ìyá rẹ̀ nínú. Láti pínísin bí i ọmọ ọdún mẹrin sí márùn-ún ni wọn ti lè bẹ̀rẹ̀ sí i fi ojú ọmọ mọ iṣẹ́ ìdílé yìí. Wọn yóò rán ẹ̀kú tirẹ̀ fún ún tí yóò sì máa kọ́ ìgbésẹ̀ ijó bàtá àti orin àwọn eléégún aláré loríṣiríṣi. Lẹ́yìn èyí ni òkìtì oríṣiríṣi ní títa kí ó tó ó kan idán pípa. Nígbà tí ọmọ bá tó dáǹgájía ní í tó ó máa gba òmìnira. Lọ́pọ̀ ìgbà ni ó sì jẹ́ pé baba rẹ̀ náà ni yóò máa bá ṣiṣẹ́ títí baba yóò fi papòdà tí yóò sì fi iṣẹ́ náà sílẹ̀ fún ọmọ rẹ̀.

## 4.1.2 Ẹgbẹ́ Eléré, Àwọn Òṣèré àti Ọnà Wọn

Bàbá, tí ó jẹ́ olórí ẹbí ní í máa sábàá jẹ́ aṣaájú tàbí olóri ẹgbẹ́ eléégún aláré kan, Ìyẹn ni pé ẹbí kọ̀ọ̀kan ní í máaa jẹ́ ẹgbẹ́ aláré kọ̀ọ̀kan. Gbogbo àwọn obìnrin ile àti ọmọ ilé náà ni yóò sì jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́. Àpẹẹrẹ àwọn ìdílé eléégún alárе tí wọ́n gbajúmọ̀ nílẹ̀ Yorùbá ni Agbégijó, Ajófẹ́èbó, Agbórákò, Ẹyẹbà, Lébe, Akéréburú, Ayélabọlááti Àjàǹgìlá. Àwọn onílù dá dúró láàyè ọ̀tọ̀ tiwọn nítorí iṣẹ́ ìdílé tiwọn náà ni ìlù lílù. Àyàn ni wọ́n ń jẹ́ ní ìran/ ìdílé wọn bí a ti sọ. Ìlù bàtá ni àwọn eléégún aláré máa ń jó. Ẹgbẹ́ eléégún aláré kọ̀ọ̀kan ní í sì í máa ní onílù tí ó máa ń lùlù fún un. Nítorí ìfọwọ́sówọpọ̀ tí ó ga tí ó máa ńwà láàrin àwọn onílù àti eléré yìí, tí ó jẹ́ pé bí kò bá sí onílù eré ṣiṣe kò lè wáyé, ni a ṣe le rí àwọn méjèèjì bí ọ̀kan. Nígbà tí wọn kò bá ní òde aré eégún, àwọn onílù lè lọ òde aré mìíràn. Asọyé ti máa ń wà nípa bí àwọn ẹgbẹ́ méjèèjì yóò ṣe máa pín èrè tí wọ́n bá jọ jẹ ní àkókò ìṣeré;ọgba ni wọ́n sábàá jìjọ máa ń pín in.

Yàtọ̀ sí onílù tí a ti ṣàlàyé nípa rẹ̀ gbogbo àwọn ìsọ̀rí ọmọ ẹgbẹ́ eléégún aláré yòókù gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ọnà wọn nìwọ̀nyí: apẹsà, olórin/elégbè, oníjó, olókìtì àti àwọn apidán. Kì í ṣe pé ààlà gúnmọ́ wà láàrin àwọn òṣeré wọ̀nyí, wípé ẹnìkọ̀ọ̀kan yóò fọwọ́ mú iṣẹ́ ọnà kọ̀ọ̀kan; ráráo! Ẹnìkan le

ṣe tó méjì mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ pàápàá, ṣùgbọ́n wọn a máa mọ ibi tí ẹnìkọ̀ọ̀kan tiní ìmọ̀-ọ́n-ṣe jùlọ. Gbogbo wọn, lọ́kùnrin, lóbìnrin ni wọ́n le pẹ̀ṣà kí wọ́n gbe orin, kí wọ́n sì jó. Ṣùgbọ́n àwọn ọkùnrin nìkan ní í máa pidán tí wọ́n sì máa ń tàkìtì. Nítorí òkìtì títa lágbara díẹ̀ ni a lérò pé ó ṣe jẹ́ pé ọkùnrin nìkan ní í máa ta á. Lara oríṣi òkìtì tí wọ́n máa ń ta ni òkìtì ọbọ, alágada, àloṣílò, rínrìnrìn àti ìgàrè. Okolonbo tàbí jẹ̀pẹ́, ẹ̀kú àwọ̀tẹ́lẹ̀, ni wọ́n máa ń wọ̀ fi tàkìtì. Ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà awo egúngún, obìrin kì í ru ẹ̀kú. Ẹni tí yóò bá pidan sì gbọ́dọ̀ ru ẹ̀kú. Ìdí pàtàkì tí obìnrin kì í fi í pidán nìyẹn. Ìdán kan le jẹ́ àdápa ẹyọ apidán kan ṣoṣo, ó sì lè jẹ́ àjùmọ̀pa apidán méjì, mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.Wọn a máa wọ aṣọ ìṣeré mìíràn tí ó bá bá eré tí wọn ń ṣe lọ́wọ́ mu lé orí òkolonbo láti pidan, wọn a sì máa lo oríṣiríṣi ìbòjú aláfigigbẹ́ nínú ìṣeré wọn.

Àjọṣepọ̀ máa ń wà láàrin àwọn apidán, olórin àti àwọn onílù lásìkò tí wọ́n bá ń pidán lọ́wọ́. Ìdí ni pé orin àti ìlù ni ọ̀nà pàtàkì láti fi bá apidán sọ̀rọ̀ lápá kan àti láti mú kí òye idán tí wọ́n ńpa lọ́wọ́lọ́wọ́ ó yé àwọn òǹwòran lójú agbo eré. Àwọn idán tí wọn máa ń pa egbẹ́máa ń lágbara ju ara wọn lọ. Àwọn idán kan wà tí ósì jẹ́ pé olórí nìkan ni ó máa ń pa wọ́n. A óò ṣì sọ̀rọ̀ nípa díẹ̀ nínú wọn nínú.

### 4.1.3 Ìgbéréká

Agbéréká ni àwọn òṣèré egúngún aláré. Wọ́n máa ń tiìlú dé ìlú, abúlé dé abúlé àti ìletò dé ìletò láti lọ ṣeré. Ní àsìkò ẹ̀ẹ̀rùn, tí òjò kò rọ̀ mọ́ ni àwọn eléégún aláré máa ń gbé eré wọn ká. Àṣà gbígbé eré ká yìí ni ó ń mú àwọnkan máa pè wọ́n ní alárìnjó, ṣ Bí ẹ̀ẹ̀rùn bá ti bẹ̀rẹ̀ ni àwọn olórí ẹgbẹ́ egúngún aláré yóó ti máa múra bí wọn yóó ṣe rìnrìn àjò wọn. Olórí ẹgbẹ́ yóó rán Òpé káàkiri àwọn ìletò, abúlé àti ìlú tí wọ́n fẹ́ gbé eré dé (Adéedèjì, 1978). Bí Òpé bá ti wọ̀lú, ọ̀dọ̀ Alágbààà ìlú ni Òpé yóó lọ láti fi àrokò tí olórí ẹgbẹ́ fi rán an jíṣẹ́. Bí Alágbààà bá ti gba àrokò, yóó fi ọ̀rọ̀ náà tó ọba ìlú,ọlọ́jà tàbí baálẹ̀ létí, bí ẹnu bá sì ti kò pé kí ẹgbẹ́aláré tó ránńṣẹ́ sí i ó wá ṣeré, ó kù kí ẹgbẹ́ náà ó gbé eré wọn wá ní àkókò tí a bá fún wọn. Yátọ̀ sí pé àwọn ẹgbẹ́ eégún aláré ránńṣẹ́ pé àwọn fẹ́ gbé eré wá, wọ́n tún máa ń lọ sí àwọn ibi ọdún ìbílẹ̀ tí wọ́n ń ṣe ní ìlú òkèèrè láti lọ ṣeré níbẹ̀. Bí àwọn ẹgbẹ́ eégún aláré bá wọ ìlú kan, ọ̀dọ̀ Alágbààà ìlú ni wọ́n kọ́kọ́ máa ń lọ. Tìlù,torin àtijó ni wọ́n máa ń wọ̀lú. Èyí ni yóò sì jẹ́ bí ìpolongo àkọ́kọ́ fún gbogbo àwùjọ náà pé àwọn eléégún aláré kan ti wọ̀lú.Ó di dandan kí Alágbààà ó ṣe wọ́n lálejò bí wọ́n bá wọ̀lú. Bí wọ́n bá ti sinmi tán, ọ̀dọ̀ ọkọ ìlú ni ó kù tí wọn ó lọ láti fi tó o létí pé àwọn ti wọ̀lú. Wọn yóò padà sílé tí wọ́n wọ̀ sí lọ́dọ̀ Alágbààà tàbí ibi tí wọ́n bá ṣètò sí fún wọn láti wọ̀ sí. Ó máa ń tó ọjọ́ kejì kí wọ́n tó lè ṣeré. Ààfin ni ibi ìṣeré àkọ́kọ́ máa ń sábàá jẹ́. Tilù, torin, tijó náà ni wọn óò tò lọ́wọ̀ọ̀wọ́ lọ sí ojú agbo ìṣeré wọn. Èyí ni yóò sì dúró bí ìpolongo eré wọn. Lẹ́yìn tí wọ́n bá ṣeré níwájúde àfin tán ni wọn yóò tó máa gbé eré ká ọ̀dọ̀ àwọn olóyè pàtàkì pàtàkì. Bí wọ́n bá ti ṣeré káàkiri tán,wọn yóò padà sí ibi tí wọ́n wọ̀ sí, wọn yóò kọjá lọ sí ìlú tàbí ìletò míràn. Ó lè gba

wọn tó ọjọ́ méjì mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ kí wọ́n tó yí àwùjọ kan ká tán. Ódúró lórí bí ibẹ̀ bá ṣe tóbi sí tí àyè sì gbà wọ́n sí.

## 4.1.4 ÈTÒ ÌṢERÉ LÓJÚ AGBO ERÉ

Bí àwọn eégún aláré bá fẹ́ ṣeré, ó ni àwọn ètò onígbèésẹ̀ mẹ́ta kan tí wọ́n máa ń tẹ̀le. Ètò yìí ni: ìṣíde, eré oníṣe, àti ikádìí.

### 4.1.4.1 Ìṣíde

Bí àwọn òṣèré eégún aláré bá ti dé òde eré, gẹ́gẹ́ bí gbogbo àwọn eléré Yorùbá, ìbà ni wọ́n kọ́kọ́ máa ń jú. Wọ́n gbọ́dọ̀ ṣe ìbà nítorí ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé àdáṣe ní í hunmọ, ìbà kì í hùnniyàn àti pé bí ekòló bá júbà ilẹ̀ dandan ni kí ilẹ̀ lanu. Wọ́n máa ń ṣèbà àwọn Irúnmọlẹ̀, wọ́n máa ń ṣèbà àwọn babańlá wọn bíOlógbojò, Ọlógbìn-ín, Ẹ̀ṣà-Ògbín, Aláràn-án-ọ̀rin, Ọlọ́jọwọ̀n àti Ọlọ́pọndà. Wọ́n tún máa ń ṣèbà baba wọn gan-an-gan, ọ̀gá tó kọ́ wọn níṣẹ́, ọba,ìjòyè àti àwọn àgbààgbà tó wà ní ìkàlẹ̀.Olórí ẹgbẹ́ ni ó máa ń ṣèbà náà, ẹ̀ṣà pípè ní í sì í fi i ṣe é.Onílù lè máa já bàtá sí ẹ̀ṣà pípè náà. Wọ́n lè dárin, kí wọ́n sìgbèé láàrin ìbà náà, ṣùgbọ́n èyí tí ó pọn dandan ni orin ti ìparí ìbà jíjú onílù yóò lùlù kárakára, wọn yóò já bàtá, àwọn olókìtì náà kò sì ní í gbẹ́yìn. Ijó orin ìlù àti òkìtì títa yìí ni wọ́n máa ń lò láti fi pààlà òpin ìgbésẹ̀ ìṣeré kan àti ìbẹ̀rẹ̀ òmíràn.

### 4.1.4.2 Eré oníṣe

Lẹ́yìn tí àwọn eégún aláré bá ti júbà tán, kí wọ́n máa ṣe oríṣiríṣi eré wọn nìṣó ló kù. Idán ni wọ́n máa ńpe àwọn eré wọn náà. Àwọn idán aládààṣe wọnkì í ní àhunpọ̀ ìtàn. Kì í sì í ṣe gbogbo idán alájùmọ̀ṣe wọn náà ní í ní àhunpọ̀ ìtàn. Ìsínjẹ tàbí ìfihàn ẹ̀dá ìtàn niàwọn idán tí wọn kò ní àhunpọ̀ ìtàn máa ń jẹ́.Irú ẹ̀dá ìtàn bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ ènìyàn, ẹranko òrìṣà tàbí ẹ̀mí àìrí mìíràn.Àhunpọ̀ ìtàn kì í gùn rárá nínú àwọn idán tó bá ní i, ó sì máań lọ tààrà, kì í lọ́jú. Idán aláhunpọ̀ ìtàn máa ń sabàá jẹ́ èyí tí òṣeré tàbí aṣèsínjẹ tí ó ju ẹyọ ẹnìkan ṣe.

Idán tí wọ́n kọ́kọ́ fi máa ń sábàá fi ṣíde eré ni ìdán ajẹmórìṣà (bí i ti Ṣàngó, Ọbàtálá)àti idán ajẹmẹ́ranko (bí i ti erè/òjòlá, ọ̀nì,ọ̀bọ/irò, ẹkùn; Adédèjì, 1969). Aládààṣe ni idán ìṣíde máa ń jẹ́, olórí ẹgbẹ́ eégún aláré náà ní í sì í máa ṣe wọ́n. Àwọn irú idán méjì wọ̀nyí jẹ mọ́ẹ̀sìn àwọn ìbọ àti ìgbàgbọ́ nínú àwọn babańlá Yorùbá. Idán ajẹmórìṣà ni wọ́n kọ́kọ́ máa ń paláti júbà àwọn òrìṣà náà. Lẹ́yìn náà ni idán ajẹmẹ́ranko. Àwọn ẹranko tí wọ́n máa ń fi hàn maa ńjẹ́ àmì àlárokò ìran àwọn orílẹ̀ tí àwọn baba ńlá yìí dá sílẹ̀, tàbí kí ó ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn babańlá náà gan-an gẹ́gẹ́ bí àwọn ìtàn akọnikàyéfì ìran náà ti fi hàn. Bí àpẹẹrẹ, babanlá àwọn ìran Erèlápà lodi erè bí ìtàn ti jẹ́ kí á mọ̀ (wo Yémiítàn 1972). Ìtàn àwọn iran ọlọ́jẹ̀ náà ní nǹkan án ṣe pẹ̀lú irò nípasẹ̀ Olúgbẹ́ẹ̀

Àgan.Asì máa ń gbọ́ tí wọ́n maa ń fi lára àwọn ẹranko náà ki àwọn orílẹ̀, ìdílé àti ìlú mìíràn. Àpẹẹrẹ ni "Ọmọ ẹkùn", "Ọmọerin,""Ọmọ erè lápà" Lẹ́yìn èyí ni wọ́n yóò máa pa àwọn idán mìíràn bí idán ajẹmábirùn (bí i eléyín wanbọ, elétí ehoro, dìndìnrìn), idán ajẹmájèjì (Gàǹbàrí, Tápà), idán ajẹmọ̀wà-ìbàjẹ́ àwùjọ (idán ọ̀dọ́kọ àti ọ̀falè, idán ọ̀mùtí, ọmọ tí ó gba ọ̀pá lọ́wọ́ afọ́jú), idán ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ àwùjọ (Ìbẹ̀wò òyìnbó D. O.; Elésèé, ọba Ìgbàjà; Kúdẹ́ẹ̀fù, ẹrú tí kò mọ ọba) idán ajẹmọ́tàn-ìṣẹ̀lẹ̀-gidi (Alátìíńgà, Jagunjagun Ìdàhọ̀mì). Idán àparelé (ìyá ọlọ́mọ, tọkọtìyàwó) ni wọ́n máa ń fi kásẹ̀ idan pípanílẹ̀. Púpọ̀ lára àwọn idán wọ̀nyí ní ó máa ń jẹ́ àjùmọ̀ṣe, ṣùgbọ́n àwọn kọ̀ọ̀kan náà lè jẹ́ àdáṣe (ìyá ọlọ́mọ, òkú òòró). Gbogbo àwọn tí wọ́n bá ń ru ẹ̀kú nínú ẹgbẹ́ ní ó lè kópa bí òṣèré nínú àwọn idán náà.

### 4.1.4.3 Ikádìí

Idán àparelé ni àṣegbẹ̀yìn idán àwọn eléégún aláré. Kò sí ìgbà tí àwọn òǹwòran kò lè náwó fún wọn ní ojú agbo eré ṣùgbọ́n ti idán àparelé ni o máa ń pọ̀ jù nítorí pé idán náà ni ó wuyì lójú jù tí abá wo ẹwà ìmúra àwọn eléré náà. Nígbà tí àwọn egúngún aláré bá ti fi idán aparelé yìí pawó tẹ́ ara wọn lọ́rùn dáadáa, wọ́n yóò kádìí eré wọn nílẹ̀. Àwọn òṣèré eégún aláré kì í foru ṣeré, bí ọjọ́ bá tí ń bora ni wọ́n yóò ti máa múra láti palẹ̀ eré wọn mọ́.Oníbàtá ni yóò ti máa fi bàtá ta wọ́n ní olobó pé ilé ti tó ó lọ. Àwọn elégbè náà yóò gba orin tí alubàtá wọn bá dá, wọn yóò máa jó, wọn yóò máa lùlù láti fi orin dágbéré pé àwọn ti ń lọ.

## 4.2 Àpẹẹrẹ Idán/Eré Díẹ̀

A kò ní í lè ṣe àpẹẹrẹ gbogbo àwọn idán eégún aláré tí a ti là sílẹ̀ lókè nítorí àkókò àti ààyè tí kò sí. Mẹ́ta wọ̀nyí: idán ajẹmọ́rìṣà, àjẹmọ́wà ìbàjẹ́ àti àparelé ni a óò fi ṣe àpẹẹrẹ.

### 4.2.1 Idán Ajẹmórìṣà

Lára àwọn òrìṣà tí àwọn eléégún aláré máa ń pa idán wọn ni Ṣàngó, Ògún, Ọbàtálá, Ẹ̀yọ̀. Bí àwọn egúngún aláré bá fẹ́ pa idán Ṣàngó, bí àpẹẹrẹ, olórí ẹgbẹ́ aláré náà ni yóó pidán náà. Òṣèré tí yóò pa idán náà yóó múra bí ẹlẹ́gùn Ṣàngónípa wíwọ gbérí Ṣàngó, yóó sán yẹ̀rì pupa àti wàbì Ṣàngó yóò sì gbé, labà Ṣàngó kọ́rùn, yóó mú oṣé lọ́wọ́ àti ṣẹẹrẹ Ṣàngó lọ́wọ́.Yóó gbé òṣù Ṣàngó tí a fi igi gbẹ́ sorí. Àwọn apẹ̀ṣà yóò máa ki Ṣàngó ní mẹ́sàn-án mẹ́wàá. Oníbàtá yóó máa lu bàtá kíkankíkan, òṣèré yìínáà yóò sì jó karakara.Lára ìlù tí oníbàtá máa ń lù fún un ni:

Oníṣàngó dẹ̀wà nù, mo he é
Oníṣàngó dẹ̀wà nù, mo he é
Bí Adédèjì (1969)ti là á yé wa, wọ́n máa ń fi àwọn idán wọ̀nyí ṣe àpọnlé àwọn òrìṣà Yorùbá ni.

### 4.2.2 Idán Ajẹmọ́wà Ìbàjẹ́ Àwùjọ

Lára àwọn idán ajẹmọ́wà ìbàjẹ́ tí àwọn eléégún aláré máa ń pa ni idán ọ̀mùtí. Bí àwọn éléégún aláré bá fẹ́ pa idán yìí, òṣèré kan yóó múra bí ọ̀mùtí, ó lè wọ dàǹṣíkítí kò bá ṣòkòtò mu, kó dé fìlà rẹ̀ ní ọ̀nà tó pani lẹ́rìn-ín, bí aláìbíkítà. Ó le dé e kó kọjá ìpéǹpéjú, ó le gẹ̀ ẹ́ sí ẹ̀yìn, ó sì le fi lé orí. Yóó wá gbé agbè ẹmu kékéré lọ́wọ́ pẹ̀lú ahá tí ó fi ń bu ẹmu mu nínú rẹ̀, yóó sì máa ta gbọ̀n-ọ́n gbọ̀n-ọ́n kiri ojú agbo eré, ó lè máa pòfóló, kó máa ṣèsínjẹ ẹni tí ń bì, kósì máa ta lulẹ̀ kiri, àwọn erò ìworan yóò sì máa bìsẹ́yìn fún un. Bí àwọn òṣèré eégún aláré mìíràn tí wọn múra bí ọlọ́pàá ṣe wá fi kóńdó gbá a kúrò ní ojú agbo, àwọn oníbàtá yóó máa fi ìlù fọhùn pé,

Ọ̀mùtí fara ṣòfò; igí dá
Ọmùtí fara ṣòfò; igí dá,
Igídá, igí dá
Ọ̀mùtí fara ṣòfò; igí dá
Ìdán yìí wà láti fi àwọn ọ̀mùtí ṣẹ̀fẹ̀, àti láti fi hàn pé ìmutipara débi kí èeyàn máa da àlàáfíà àwùjọ láàmú lòdì sí òfin; lọ̀rọ̀ kan pé ìmutípara kò lérè (Adédèjì 1969).

### 4.2.3 Idán Àparelé

Idán ìyàwó, tàbí tọkọtìyàwọ ni àwọn eégún aláré máa ń sábàá pa gbẹ̀yìn ìṣeré wọ́n lójú agbo. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ idán yìí ní í máa rẹwà jù lọ nínú àwọn idán wọn. Owó iyebíye ni wọ́n máa ń ná láti pèsè aṣọ àti ohun ọ̀ṣọ́ ìmúra ìyàwó. Bí àwọn eégún aláré bá ti ń pa ọ̀kan nínú àwọn idán yìí, eré ti ń wá sópin nìyẹn. Ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń sọ pé "Bí eégún bá dìyàwó, Baálẹ̀ a dìde". Ó lè jẹ́ pé ìyàwó tó ń fọ́mọ lọ́yàn ni idán ìyàwó tí àwọn eégún aláré máa fi ṣe idán aparelé, tàbí ọkọ àti ìyàwó rẹ̀ tí wọ́n jìjọ ń kọ́wọ̀ọ́ rìn.Bí ó bá jẹ́ pé ìyàwó tí ó ń fọ́mọ lọ́yàn ni, eégún tó múra bí ìyàwó, tó gbé ọmọ lọ́wọ́ ni wọn ó fi hàn. Ọmọláńgidi ni yóò fi ṣe ọmọ náà, yóó fi aṣọ tàbí igi ṣe ọyàn, yóó di bèbè sídìí yóò sì máa ṣe ìsínjẹ fífún ọmọlọ́yàn. Yóó máa jó káàkiri ojú agbo, wọn óó sì máa kọrin pé:

Ọmọ lerè ọjà,
Ọmọ lerè ọjà ò
Èdùmàrè kó fún gbogbo wa lọ́mọ
Ọmọ lerè ọjà (Adédèjì 1969)

Arokò ìwúre tíwọ́n ń fi idán náà pa fún àwọn òǹworan wọn ni orin yìí ti túmọ̀ yẹn. Wọ́n ń wúre fún àwọn òǹwòran wọn wí pé Kí Olódùmarè pèsè ọmọ fún wọn tí yóò jẹ́ ààrọ̀ lẹ́yìn tí wọ́n bá papòdà tán tí ọ̀rọ̀ wọn kò fi ní í dàbí ti ejò tí ó gba orí àpáta kọjá lásán tí kò ní ipa kankan. Àwọ yorùbá gbà pé ọjà tàbí àjò ni ayé yìí, bó pẹ́, bó yá, a ó padà rọ̀run. Bí èèyàn bá ṣá lọ sí ọjà èèyàn kì í sun ibẹ̀.

Bí wọ́n ti ń pa idán yìí ni àwọn òǹworan yóò máa ta wọ́n lọ́rẹ lóríṣiríṣi. Bí eré yìí bá ti ń lọ lọ́wọ́, àwọn ẹgbẹ́ eléré yòókù yóó ti máa palẹ̀ mọ́, bí wọ́n bá sì ti palẹ̀ mọ́ tán, wọn yóò yí orin padà sí orin ìdágbéré. Ẹ̀ṣà díẹ̀ díẹ̀ le máa yí wọnú ẹ̀ ṣùgbọ́n kì í pọ̀ rẹrẹ, wọn yóò padà sí ilé tí wọ́n dé sì nínú ìlú tí wọ́n gbé eré wá náà. Àpẹẹrẹ orin ìdágbéré kan nìyí.

Ilé yá, ilé mámà yá o
Ká má ba à dáláṣejù, ilé yáá
Àwọn méjìmírànn tó gbajúmọ̀ọ̀ nínú orin ìdágbére àwọn eégún aláré ni,
Ẹ jẹ́ ká relé, ilé là ń lọ
Ọ̀jẹ̀ kan ò ṣàwoṣàwo, kó gbàgbéilé

Àwa ń lọ,ó dìgbà ó ṣe
Ká má fikú yara wa,
Ká má fàrùn yara wa

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ṣagbéyẹ̀wò eré oníṣe eégún aléré. A ṣe àlàyé pè kò sí awuyẹwuyẹ lórí pé eré oníṣe ni eégún aláré. A ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá ìṣeré eégún aláré. A sọ pé iṣẹ́ ìran ni. A jíròrò lórí ẹgbẹ́ eégún aláré, àwọn òṣèré àti iṣẹ́ ọnà wọn, a ṣe àlàyé bí wọn ṣe máa ń gbé eré káàkiri àti ètò onígbèésẹ̀ mẹ́ta (ìṣíde, idán pípa àti ìkádìí) tí wọn máa ń tẹ̀lé nínú ìṣeré wọn kí a tó wá ṣe àpẹẹrẹ díẹ̀ nínú irú àwọn eré wọn náà.

Ìgbésẹ̀ inú ìṣeré àwọn eleégún aláré kì í sábàá yàtọ̀ síra, ṣùgbọ́n oríṣiríṣi ni idán tí eléégún aláré kọ̀ọ̀kan máa ń pa.Bẹ́ẹ̀ sì ni ẹgbẹ́ aláré kọ̀ọ̀kan ló ní ìmọ̀-ọ́n-ṣe nínú ọ̀nà ìṣeré wọn kan, ó kéré tán tí ó ju tẹgbẹ́ mìíràn lọ. Irú ọnà iṣeré bẹ́ẹ̀ ni ẹgbẹ́ náà yóò gbajumọ̀ fún jù lọ. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, kò sí egúngún aláré tó le jó bíi Lébe, kò sì sí olókìtì bí Ẹyẹbà. Bí ó bá di pé kí á pẹ̀ṣà tó gbayì, Àjàǹgìlá ló nìyẹn. Bó bá wá jẹ́ ká padán oríṣìíríṣìí ni, kò séégún aláré tó le padán Ayélabọ̀lá. Nínú ká ṣàfihàn oríṣiríṣi ère làwọn Agbégijó ti gbayì jùlọ.

## 6.0 IṢẸ́ÀMÚṢE

1. Àwọn orúkọ mìíràn wo ni wọ́n tún máa ń pe àwọn eléégún aláré. Kí sì ni ìdí tí ó fijẹ́ pé orúkọ eégún aláré ni ó mọ́yán lórí jù lọ.
2. Irú ìlù wo ni àwón elégún aláré máa ń jó sí? Ní ṣókí, jíròrò lórí àjọṣe àwọn onílù náà pẹ̀lúàwọn ọmọ ẹgbẹ́yòókù.
3. Ṣàpèjúwe ìṣeré idán eégún aláré méjì tí ó bá wù ọ́?
4. Kọ méjì nínú àwọn orin tí àwọn egúngún aláré máa ń kọ nínú àwọn idán wọn sílẹ̀ kí o sì ṣàlàyé ìtumọ̀ ohun tí wọ́n ń sọ nínú rẹ̀ ní kíkún?

5. Dárúkọ ẹgbẹ́ egúngún aláré mẹ́ta àti irúfẹ́ idán tí ìkọ̀ọ̀kan wọn gbajúmọ̀ fún jù lọ?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Adédèjì, J.A. 1969. "The Alárìnjó Theatre, Àpilẹ̀kọ fún Oyè Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ gíga, Yunifásitì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

____________ 1972. "The Origin and Form of the Yorùbá Masque Theatre". *Cahier d'études Africaines*, 12:2, o.i 255-276.

____________ 1978.Alárìnjó: "The Traditional Yorùbá Travelling Theatre" nínú Oyin Ògunbà àti Abíọ̀lá Irele (olóòtú) *Theatre in Africa* Ìbàdàn: Ìbàdàn University Press.

Babalọlá, S. A. 1966. *Content and Form of Yorùbá Ìjálá*. Oxford University Press, London.

Babáyẹmi, S.O. 1980. *Egúngún Among Yorùbá Ọ̀yọ́ Yorùbá*. Ọ̀yọ́ StateCouncil of Arts and Culture,Ìbàdàn.

Gotrick, I. 1984. *Apidán Theratre and Modern Drama: A Study in a TraditionalYorùbá Theatre, its Influence on Modern Drama by Yorùbá Playwrites.*Almqvist and Wiksell International, Armsterdam.

Johnson, J.A. 1921. *The History of Yorùbá: From the Earliest Time to the Beginningof the British Protectorate*. Routledge and Kegan,London.

Ògúndèjì, P.A. 1992.*Yorùbá Drama 1 (Eré Oníṣe Yorùbá 1)*. Ìbàdàn: Centre forExternal Studies, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

_____________ 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigerian Example*Ìṣẹ̀ṣe monograph Series, Ìbàdàn Cultural Studies Group,Ìbadàn.

Ògúndèjì, P.A. 2005. "Forms and Functions ofTraditional Theatre Practice in Nigeria" nínú S. AdémọláÀjàyí olóòtú,*African Culture and Civilization,*Atlantis Books, Ìbàdàn àti Ìbàdàn Cultural Studies Group, University of Ibàdàn,o. i. 211– 245, Ìbàdàn